Nelson books give sound education

978 126 240 0

# ÌRÌNKÈRINDÒ NÍNÚ IGBÓ ELÉGBÈJE



D.O. FÁGÚNWÀ

# IRINKERINDO NINU IGBO ELEGBEJE



Nkan ti a kọ ṣe akiyesi ni ọwọ̀n nla kan ti o ba oju ọrun Ìọ.

# IRINKERINDO NINU IGBO ELÉGBÈJE

## APA KẸTA

## OGBOJU ỌDẸ NINU IGBO IRUNMALẸ


Lati Ọwọ

D. O. FAGUNWA

Ẹniti O kọ iwe
"Ogboju Ọdẹ Ninu Igbo Irunmalẹ",
"Igbo Olodumare", "Ireke Onibudo", etc.



Nelson Publishers Limited

Published by

Nelson Publishers Limited

*in assocation with*

Evans Brothers (Nigeria Publishers) Limited,
Jericho Road, PMB 5164, Ibadan, Nigeria.

Tel: 02-2414287, 2414394, 2413708

E-mail: evans@skannet.com
evans@evanspublishers.com.ng
Web: www.evanspublishers.com.ng

© Nelson Publishers Limited 2005

First published 1954

Reprinted 1955, 1956 (twice), 1957, 1958, 1959 (thrice), 1960 (twice), 1961, 1966, 1968, 1979, 2005, 2007, 2008, 2011

All rights reserved. No part of this publication may be reproduced, stored in a retrieval system, or transmitted in any form or by any means, electronic, mechanical, photocopying, recording or otherwise, without the prior permission of Nelson Publishers Limited.

ISBN 978 126 240 0

*Printed by NERVES Molete, Ibadan.*

## ỌRỌ AKỌSỌ

Iwe yi wa fun gbogbo enia ni ilẹ Yoruba, o wà fun ọmọde, o wà fun agbalagba, o si wà fun ẹnikẹni lode aiye ṣa ti o mọ ede Yoruba ikà dãdã. Ni pataki, iwe yi wà fun awọn ọmọ ile iwe lati kà gẹgẹ bi iwe klas wọn ni klas ti olukọ ba rò pe o yẹ fun, bẽni bakannã l'o tun wà fun awọn ti nṣe idanwo Kembrij lati fi kọ ijinlẹ Yoruba.

Ẹ o ri'i pe mo fi iwe nã juba ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn wà laiye loni, mo gba aṣẹ lọwọ awọn wọnyi nwọn si ti fi aṣẹ nã fun mi pe ki nfi juba awọn, ṣugbọn o ni idi pataki ti mo fi fi iwe yi juba wọn. Awọn wọnyi wâ lãrin awọn enia pataki ti mo ro pe o yẹ ki ọmọ Yoruba mã ranti lati iran de iran. Professor Margaret Read, obinrin ni, o si yẹ ki ọmọ Yoruba kọ ọgbọn lara obinrin yi, pupọ ninu wa ni o ṣì nwipe kini obinrin le ṣe, pẹlu irọju si ni awọn obi miran fi nfi ọmọ wọn si ile iwe bi ó ba sa ti lè jẹ obinrin. Margaret Read ni Ọga Ile Ẹkọ nla ti ọpọlọpọ awọn ti o ba lọ si ìlu Gẽsi lati kọ bi a ti ṣe nṣiṣẹ olukọ ti nkọ iwe wọn, ogunlọgọ enia lati origun mẹrẹrin aiye l'o nwa, a ko si le ka iye awọn ọkunrin ti o nṣiṣẹ labẹ obinrin yi ni bi a ti nsọrọ yi. Ṣugbọn ọmọluwabi ni, ko jẹ fi oju pa ẹnikẹni rẹ̀ ko si mọ ti ara rẹ̀ nikan. Apẽrẹ ni eyi fun gbogbo yin, ẹnyin enia wa.

Hon. R. A. McL. Davidson ti iṣe alakoso ẹkọ ni Nigeria lakoko yi jẹ ẹnikan ti o ti pẹ ni ilẹ wa. Lõtọ ọpọlọpọ Alakoso Ẹkọ l'o ti wà ni Nigeria ri, ṣugbọn pupọ ninu wọn l'o jẹ pe nwọn ti ibomiran wa ṣe Alakoso Ẹkọ ni Nigeria ni lai jẹ pe awọn pãpã de Nigeria ri. Ko ri bẽ fun Davidson, o pẹ ni ilẹ wa dãdã, o bẹrẹ lati ipo kekere, o ṣiṣẹ titi o fi de ipo giga. Ko si ẹni nã ti o le mọ Davidson ni akoko ti o fi nṣe oludanwo ti o nyi ile iwe kekere kiri ti yio ri i pe o de ipo nla yi loni ti ẹnu lè yà. Onişẹ ni ọkunrin nã, igbega rẹ̀ si to ẹkọ fun iwọ ati emi.

Igbesi aiye Bishop S. C. Phillips ni nkan pataki lati kọ ọmọ Yoruba. O jẹ ẹniti a nilati mã ranti lati iran de iran wa. Ẹnyin

nã mọ pe àbùkù awa Yoruba ni eke ṣiṣe, ati sọ ododo a mã ṣoro fun ni. Bi o ba wi fun ẹnikan pe "Maṣe ba mi lo Yoruba," itumọ ọrọ rẹ ni "Maṣe purọ fun mi". Igbati a ba si wò bi oju Yoruba ti là to ki Gẹsi tilẹ to goke, ti o si jẹ pe kò si ẹya kan ni Nigeria ti o le wipe on laju ju Yoruba lọ titi di oni oloni, ẹ o ri i pe bi a ba le mu iru abawọn bayi kuro lara wa ilọsiwaju wa yio mã ya gbogbo ara aiye lẹnu ni. Ṣugbọn Bishop Phillips fi han ni pe ki iṣe gbogbo ọmọ Yoruba ni o npurọ. Tani ẹni nã ni ode aiye yi, yala dudu, yala funfun ti o le wipe Bishop Phillips ba on lo Yoruba? Ko si, afi ẹniti o ba mã pe aguntan ni malũ, ti o pe mọto ni kẹkẹ, ti o pe Ọmọtunde ni Akintunde, ti o pe ara aiye ni ara ọrun. Õtọ nikan ni Bishop yi mã nsọ, gbogbo enia si ti mọ bẽ fun u. Apẽrẹ ni eyi fun gbogbo wa. Bi ẹru ba nba ọ lati sọ õtọ maṣe gbagbe Bishop Phillips Olododo nitori Bishop yi ti o jẹ aṣãju pataki fun ni kò fi eke kọ iwọ ati emi.

Ọba Ọlagbegi II ti o jẹ Ọlọwọ ni Ọwọ̀ loni jẹ ẹni akiyesi pataki kan. Igbesi aiye rẹ fi han ni ohun ti enia lẹ fi ọwọ ara rẹ ṣe. Tani ẹni nã ti o le gbọ ki Ọlọwọ sọ ede Gẽsi ti ko ni rò pe o ti jade ni University tabi pe nwọn bi i si Ilẹ Gẽsi ni? Bẽni o kọ nkan rẹ fun ara rẹ ni. Ko si ẹniti o le de Ọwọ loni ti yio bojuwo ẹhin ti ayipada rere gbogbo ti o de lakoko Ọlagbegi II ko ni yà lẹnu, bẽni ko si ọmọ Yoruba ti yio gbọ ki Ọlọwọ yi sọrọ lãrin awọn igbimọ pataki gbogbo ti o mã nlọ ti ko ni fi ọba yi ṣe foriforí. Ọba Ọlagbegi II kuro ni nkan yẹpẹrẹ, afi bi a ba mã tan ara ẹni jẹ.

Miss J. A. Mars pẹ pupọ ni ilẹ wa, o duro gẹgẹ bi àna fun pupọ ninu ọmọ Yoruba nitori ọpọlọpọ awọn obinrin ti o ti kọ ni nwọn npe e ni iya ti nwọn si ti di iyawo enia pataki kakiri. Gbogbo agbara ni obinrin nã fi ṣiṣẹ lọdọ wa, bẽni ọpọlọpọ ọmọ ti nwọn bi loju rẹ ti wọ ile ọkọ lati ọjọ pipẹ, a ko gbọdọ gbagbe obinrin yi lailai.

Miss J. V. Herklots jẹ obinrin ti o mọ iwe lọpọlọpọ. Obinrin yi ko ba ti ṣiṣẹ labẹ C.M.S. bi o ba ṣe pe owo l'ó nwa kiri. Loni, on ni Alaga ipade awọn alakoso ẹkọ ti nwọn jẹ enia pataki gbogbo ni ilẹ Yoruba. Bẽni igbesi aiye obinrin nã fi han ni pe nkan miran wà ti o lagbara ju owo lọ. Kì enia mu



ki aiye ọmọ ẹlomiran dara lagbara ju ohun gbogbo. O tun fi han ni pe obinrin le ṣe nkan nla; nitori bi o ti jẹ obinrin yi awọn ọkunrin nla nla gbogbo nṣiṣẹ labẹ rẹ di bi a ti nsọrọ yi. Apẽrẹ fun awọn obi ni eyi.

L. Murby jẹ ọrẹ ọpọlọpọ awọn ọmọ Yoruba, o fi iwa rẹ fà wọn mọra, o jẹ apẽrẹ pe enia dudu ati enia funfun le jẹ ọrẹ ara wọn. Ọga Ile Ẹkọ Giga ni Gbobi ni ọkunrin nã ti jẹ ri, ṣugbọn loni, o nṣiṣẹ ni ibiti nwọn ti ntẹ iwe ni Ilẹ Gẽsi. Ṣugbọn, ìwà kì ifi oniwà silẹ, agodongbo inu ẹtu nba ẹtu lọ. Mr. Murby nti igbega de igbega ni ibi iṣẹ rẹ. Apẽrẹ ni eyi fun gbogbo wa.

Mr. D. R. G. Gwynne-Jones ni ọga Ile Ẹkọ Giga ti Ijọba ni Ibadan ti nwọn ti nkọ awọn enia ni iṣẹ olukọ. Igbati ọkunrin yi de, ọdun meji ni awọn akẹkọ nlo, ile ti o wa fun ilo awọn akẹkọ ko ju iba diẹ lọ. Loni, awọn akẹkọ nlo ọdun mẹrin, ile pọ lọ bẽrẹ fun ilo wọn. Bẽni bi nkan ba ti ntobi to ni iṣoro rẹ ntobi to ṣugbọn, Gwynne-Jones bori iṣoro tirẹ patapata. Lõtọ ó mọ iwe dãdã, a si mã ṣe eto dãdã, bẽni a mã ṣiṣẹ bi o ti yẹ, ṣugbọn ohun pataki ti o ti ọkunrin nã lẹhin ju ni ti Ọlọrun ti o gbà gbọ. Apẽrẹ ni eyi fun iwọ ati emi, bi a ba fẹ ki orilẹ ede wa yi mã ti ibi giga de ibi giga a ko gbọdọ ṣai fi ara ti Ọlọrun Ọba. Eleyi l'o mu ki ẹri ọkan Gwynne-Jones lagbara tobẽ nitori mo ti ba a lò ri mo si ri i pe ki ifẹ ki on ṣe nkan si ẹnikẹni ti ẹri ọkan on yio fi da on lẹbi. Ẹ maṣe gbagbe eyi ẹnyin enia wa.

Revd. M. J. Ade Ṣijuwade, ọga mi. Ko si ọjọ kan ti mo nranti Revd. Ṣijuwade ti ọkan mi ko nsure fun u. Labẹ rẹ ni mo ti kọ ṣe iṣẹ olukọ kekere; ṣugbọn lai si imọran ọkunrin yi, lai si iwe rẹ ti mo yá ti mo kà, lai si atilẹhin rẹ, nko le to ẹniti o nwọ Ile Ẹkọ Giga ni ode Ọyọ; lai si de ile ẹkọ yi, nko le to ẹniti nkọwe fun ẹnikẹni lati kà rara.

Mo dupẹ lọpọlọpọ lọwọ gbogbo ẹnyin ọga ile iwe ni ilẹ Yoruba fun bi ẹ ti ṣe nlo gbogbo awọn iwe mi tẹlẹ ri, mo dupẹ pẹlu lọwọ ẹnyin ti ẹ nyan iwe fun ilo awọn ọmọ ile iwe ti o jẹ pe ẹ yan iwe mi fun ilo awọn ọmọ wa. Ṣugbọn ẹ maṣe ro pe emi ni ẹ nṣe iwọnyi fun, mo fẹ ki ẹ mọ pe ẹ nṣe e fun iran iran ọmọ wa. Ero ti emi pãpã ni pe ki nsa ipa mi to bi o ti yẹ lati le mu ki awọn ọmọ ile iwe wa le mã fẹ lati ka iwe ni ede wọn

idi rẹ̀ si ni eyi ti o fi jẹ pe bi ọmọ kan ba ti bẹrẹsi ka iwe wọnyi, yio fẹ ki on mọ ibiti o gbẹhin si, igbati ọmọ kan ba ri i pe Irinkerindo wọle de, yio fẹ ki on le mọ ohun gbogbo ti o wa ṣe. Lẹ̃kan si i, mo dupẹ lọwọ gbogbo yin o, bi ẹ si ti nti awọn iwe mi wọnyi lẹhin yi, Olodumare ti gbe akengbe ibukun, ti yio tu le ori gbogbo yin karikari.

D. O. FAGUNWA



## DEDICATION

*Dedicated, by permission, to the following:*

*Professor Margaret H. Read, C.B.E., Ph.D., M.H., formerly Head of Colonial Department, University of London, Institute of Education.*

*Hon. R. A. McL. Davidson, C.M.G., the first Inspector-General of Education, Nigeria.*

*The Rt. Revd. Bishop S. C. Phillips, M.A., L.Th., the first Vicar-General of the Yoruba country.*

*Ọba Alaiyeluwa Ọlagbegi II, the Ọlọwọ of Ọwọ.*

*Miss J. V. Herklots, M.A., Diocesan Education Secretary-General, C.M.S., South-West Nigeria.*

*Miss J. A. Mars, formerly Principal of Elementary Training Centre, Akure, Nigeria.*

*L. Murby, Esq., B.A.*

*D. R. G. Gwynne-Jones, Esq., M.A., Dip.Ed., at one time Principal of Government Teacher Training College, Ibadan, Nigeria.*

*The Revd. M. J. Ade Sijuwade, Vicar, St. Peter's Church, Inisha, Oshogbo.*

*also to the memory of*

*The Rt. Revd. Bishop Samuel Ajayi Crowther.*

*A. K. Ajiṣafẹ, author of "Aiye Akamara", etc.*

*D. A. Ọbasa, author of "Iwe Akewi".*

*E. A. Akitan, author of many works in translation.*

*Revd. J. S. Adejumọ, Vicar, St. Phillip's Church, Aiyetoro, Ile Ifẹ.*

## IFIHAN


Irinkerindo wọle de .. .. .. .. 1
Ibẹrẹ irinajo si oke ironu ti mbẹ ninu igbo elegbeje 16
Alabapade ẹlẹgbara .. .. .. .. 31
Ilu awọn èdìdàrẹ́ ni ibiti omugọdimeji ti nṣe ọba wọn .. .. .. .. .. 38
Omugọdimẹta g'ori oye ṣọpọnna gbe omugọdimeji lọ .. .. .. .. .. 49
Ẹbọra igberaga-ibanujẹ ati ahọndiwura iyawo rẹ̀ 55
A fi oju wa ri ọrun apadi .. .. .. 60
Wèrédìran ti ngbe ile òmùgọ̀parapọ̀ .. .. 71
Igbeyawo Irinkerindo pẹlu aburo olókun iwin inu omi .. .. .. .. .. 76
Ilu itanjẹ-enia .. .. .. .. 101
Ogun ibode igbo elegbeje .. .. .. 109


# IRINKERINDO WỌLE DE

Aiye kun fun ibugbe iyanu, ọba bi Ọlọrun ko si, Olodumare ni nṣe alakoso ohun gbogbo ti mbẹ ni ode aiye ati ode ọrun, iyanu ni aiye pãpã jẹ: aiye kun fun enia ẹlẹsẹ meji ati ẹranko ẹlẹsẹ mẹrin, ejo afaiyafa ati ẹja ti nkakiri inu omi, ẹiyẹ ti nkọrin bi fere ati alagẹmọ ti Olodumare wọ̀ ni oniruru aṣọ. Oke ati pẹtẹlẹ, õrun ati oṣupa, awọsanmọ ati erupẹ ilẹ, gbogbo iwọnyi jẹ iyanu. Bakannã ni ọrọ sisọ lasan yi jẹ iyanu, eyiti mo si gbọ ni ijọsi ni mo ni ki nba yin sọ loni, ẹnyin ọmọ enia. Bi mo si ti nfẹ sọ fun yin yi, mo fẹ ki ẹ jẹki o wọ ibi kọ́lọ́fín agbari yin lọ, ki ẹnyin ti ẹ ngbọ ọrọ yi, fi ọrọ nã ṣe onjẹ, ati pãpã ẹnyin ọmọ ile iwe, ki ẹ gbadun rẹ̀ bi ọbẹ adiẹ pataki, ti gbajumọ obinrin se, ti o din ti o gbẹ tíkẹ́tíkẹ́.

Lọganjọ oru ọjọ kan bayi ni, mo dede gbọ, ojo bẹrẹsi ,kù nigbati mo si dide ni ibusun mi ti mo yọ oju wo ode, mo ri gbogbo ayika, o ṣokunkun dudu, bẽni akoko oṣupa ni, afi bi ẹni pe awọsanmọ ti pinnu lọkan rẹ̀ pe on ko ni tanna fun enia mọ. Awọn adiẹ sunlọ tantan, afẹ̃fẹ tutu rọra nfẹ, awọn ekute njẹ ẹ̀rún onjẹ lãrin àgbàlá, bi enia ko ba fetisilẹ tan ko le gburo ẹnu wọn, ṣugbọn òwìwí nkigbe lẽkọkan, mo si gbohun ẹlulu, bẽni adan fẹrẹ fi iyẹ gbá mi lori, nitori oru ni akoko igbadun fun ẹranko nã. Bi mo ti nwo ode ni imọnamọna nbù lẽkọkan, ibiti nko ba si ri tẹlẹ ri, igbati imọnamọna ba bù bayi emi a ri wọn. Nigbati o ṣe ti mo bẹrẹsi ronu, nko mọ igbati mo bẹrẹsi sọrọ si ita ti mo ni, "Aiye yi kò mà dọgba o, ibiti àgbẹ̀ ti njẹ onirũru onjẹ ninu ahere oko, ni alãru ti nwa gãri mu kakiri oju ọna, ibiti ọba ti njoko lori itẹ ni talaka ko le joko lori aga, ọlọgọrun apo nkakiri inu aiye bẽni ẹniti ko ri tọrọ jẹun nã nrin kiri, akoko ti awọn ẹlomiran ba njo ti nwọn nyọ ayọ nla awọn ẹlomiran a mã sọkun nwọn a kun fun ibanujẹ gidigidi. A! Ọgbọn Olodumare ta imọ enia yọ."

Bi mo ti nsọrọ bayì, afi igbati ẹnikan dede da mi lohun ni ẹgbẹ ogiri ile mi, o ni, "Bẹni, maṣe jẹki eleyi ya ọ lẹnu, iwọ

ọrẹ mi oju ferese, bi nkan ko ba ri bẽ olukuluku ẹda alãye iba wà ni itẹlọrun, nwọn iba duro si oju kan bi adagun omi, ni ọjọ ti ẹnikan ba ti wipe ibiti on de ni inu aiye yi to, igbadun oluwarẹ̀ de opin, ẹniti o wà ni ode aiye ti ko mura ilọsiwaju dabi oku lãrin alãye, bi aiye ba kun fun ayọ, ọmọ enia ko ni mọ ati kọ ibanujẹ silẹ, bi aiye ba kun fun owo, ọmọ enia ko ni mọ ipo ti talaka wà, bi aiye ba kun fun iṣẹgun ọmọ enia ko ni mọ bi a ti nyọ nigbati a ba bori iṣoro. Nitorinã, iwọ ọrẹ mi oju ferese, ti inu Ẹlẹda ye Ẹlẹda ki o to da enia bi o ti da a."

Ẹru bà mi nigbati mo gbọ ọrọ yi, ki Olodumare gba ni lọwọ ọrẹ airotẹlẹ ti nda ni lohun lọganjọ oru. Bi ọkunrin nã ti nfẹ pari ọrọ rẹ̀ ni imọnamọna bù ti mo wo ibiti ọrọ nã ti wa, mo ri i, ọ lóṣo gọ́ú si ẹba ogiri ile mi ; mo ri i, o wọ ẹwu penpe bi ẹwu ọdẹ, o gbe ibọn kan tì si ẹgbẹ ogiri.

Eleyi ko ye mi, njẹ ki nla ẹnu ki nbẽre ohun ti nwa, ṣe ni òjò nla bẹrẹ ti ọkunrin nã si kan ilẹkun ile mi, o ni, "Jọwọ ṣi 'lẹkun fun mi, ọrẹ mi ;" emi nã ba ṣi i fun u.

Igbati o wọle tan ti mo ri i ni mo mọ pe enia pataki ni, nitori oju ole yatọ si oju ọmọluwabi, ọrọ ẹnu ole yatọ si ti ọdẹ aperin. Mo ki i on nã si ki mi dãdã, mo gbe aga fun u, o joko, emi nã joko le aga kan mo kọju si i. Bi mo ti njoko ni o bẹ mi pe ki nfun on ni omi mu, mo ba dide mo bu omi fun u. Lẹhin ti o mu omi tan mo tun wa joko, ibiti mo si ti npete ki nbẽre bi mo ti ṣe dede ri i ni ọganjọ oru ni on nã berẹsi ọrọ isọ o ni :

"Ohun gbogbo ti mbẹ ni ode aiye ni o ni idi wọn : gbongbo ni idi igi ; orisun ni idi omi ; ẹyin ni idi akukọ—bi o ti ṣe dede ri mi lakoko yi ko ṣai ni idi pataki kan. Emi ni ọkunrin nã ti orukọ rẹ̀ njẹ Irinkerindo ti ngbe ile Alarinkiri. Ọjọ pẹ ti mo ti nwa ọ kiri, ko si ibiti mo ṣalai wa ọ de ni ode aiye yi, nitori ki baba mi to ṣe alaisi o ti wi fun mi pe ki nwa ọnakọna lati ri ọ ki nto kuro lori ilẹ aiye, ki nsọ nkan ti oju mi ti ri sẹhin fun ọ, nitori ki iwọ ba kede rẹ̀ fun awọn olugbe inu aiye, eleyini le mu anfani ba awọn ọmọ enia ki nwọn fi ọgbọn kun ọgbọn inu wọn. Oni yi ni ẹnikan to tọka si ile rẹ hàn mi ti mo fi wa ṣe bayi ri ọ. Emi iba si ti wọle ki o to ri mi ṣugbọn nko fẹ wọle lãrin oru, bẽni ãrin oru ni mo de ile rẹ. Nitorinã





inu mi dun pupọ lati mọ—ọ loni. Ki Olodumare da ẹmi si, riri ti mo ri ọ yi ti fi han mi pe ọrẹ pataki ni a mã jẹ fun ara wa. Nitori, ki a tilẹ wipe a ti mọ ara wa tẹlẹ ri ni, o ko le gba mi tọwọtẹsẹ ju bi o ti gba mi yi lọ. Mo dupẹ o."

Bayi ni ọkunrin nã sọ, nigbati o si pari ọrọ rẹ̀ emi nã bẹrẹsi ọrọ temi mo ni, "Ọrẹ mi, Irinkerindo, iwọ ni mo ṣe bayi ri !—Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun Ọba. Ọjọ ti pẹ nisisiyi ti mo ti ngburo rẹ, mo si ti nṣe aniyan ki nle mọ-ọ ṣugbọn a ko ba ara wa pade. Mo ti gbọ bi o ti lọ s'oke s'odo ni ode aiye yi ti o nwa ọgbọn kiri ati pe bi o si ti jẹ wipe baba rẹ fẹran rẹ ti o si tọju rẹ bi baba ti itọju ọmọ. Okiki iwọ pãpã ti kan jakejado aiye, ṣugbọn ayọ kun ọkan mi loni wipe a fi oju ri ara wa. Nipa eyiti o wi, kekere ni eyini, ṣugbọn jẹki a fi gbogbo iyoku d'ọla, nigbati ilẹ ba mọ ng o mu awọn nkan ti mo fi nkọwe, ng o si kọ ohun ti o ba nfẹ silẹ fun ọ. O ku abọ, o ku irin nã."

Bayi ni mo sọ fun ọkunrin nã, niwọnigbati o si ti jẹ pe gbogbo ile ti sun tan bamubamu, ti o jẹ pe emi nikan l'o kù ti ko sun ninu ile wa, emi ni mo lọ fi ọbẹ̀ ra ina ti mo wa onjẹ fun u. Lẹhin igbati o jẹun tan mo fun u ni iyãra kan ninu ile wa, mo fun u ni aṣọ bibora, lẹhin eyi a ki ara wa o d'ọla emi nã wọ iyãra mi lọ.

Atete sùn l'atete jì, emi ni mo ji kẹhin ninu ile wa ni ọjọ keji. Igbati a jẹun ãrọ tan, mo bọ si ibi tabili mi, mo ko awọn ohun ikọwe jọ, mo si pe e ki o joko ti mi ki o bẹrẹsi sọ itan igbesi aiye rẹ̀ fun mi. On nã ba bẹrẹ o ni :

"Iwọ ọrẹ mi, nkan ti ng o ba ọ sọ yi, maṣe gbagbe lailai, fi i si ipamọ, gbogbo nkan ti mbẹ ni ode aiye gbã ni o ni igbẹhin wọn : igbẹhin owurọ ni ọsan ; igbẹhin ọsan ni alẹ ; igbẹhin enia ni iku ; igbẹhin onjẹ ni ori ãtan ; igbẹhin igba ojo ni igba ẹrun, igbẹhin odo gbogbo ti mbẹ ninu aiye kò si ju okun lọ. Bẽni iwa enia ni igbẹhin rẹ̀, ẹniti o ba nṣõre fun ọmọnikeji rẹ̀ ngbin eso iwa silẹ bẽni ọjọ ti o ba mã ka eso iwa, oju ìkà enia yio mã pọn kankan. Igbẹhin ẹniti nla ọwọ ni iyi, ṣugbọn ètẹ́ ni igbẹhin alahun. Ẹniti nlawọ wà ninu gbajumọ, ọwọ lilà ko le sọ ni di talaka lailai, nitori aṣĩri ẹniti nlawọ ko le tu bi aiye kere bi kò ju akengbe lọ. Ṣugbọn, mọ̀ daju pe inakuna yatọ si ọwọ lila, nitori oninakuna ni ẹniti o sọ ori ara rẹ̀ nu ti o nfọnka

si ibiti kò yẹ, abamọ ni igbẹhin iru ẹni bẹ̃, ṣugbọn, sibẹ nã, oninakuna tun ni igbadun tirẹ lọtọ, oninakuna le jẹun si inu ara rẹ̀, ṣugbọn alahun a mã gbe ọbẹ ọjọ mẹwa le ina a tun mã fi omi si i. Gbogbo owo ti o ti nna lati ana ti mo ti de yi jọ mi loju gidigidi, ṣugbọn nkan ti o ngbin silẹ yi, o kò ni ṣai ka eso rẹ̀ lọjọ kan. Mo dupẹ mo tun ọpẹ da, ki Olodumare ṣe wa ni ọrẹ ara wa di alẹ o."

Nigbati ọkunrin nã dakẹ ọrọ isọ mo fesi fun u, mo ni: "Irinkerindo, mo dupẹ lọwọ rẹ gidigidi. Ko si bi a ti le ṣe ifa ki ó má huwa ekurọ, ko si bi a ti le ṣe ẹniti o nkakiri ẹhin odi ki ọgbọn rẹ̀ má ta ti ẹniti ko kuro loju kan yọ. Mo da ṣaṣa agbẹ, ọ̀bùn ara ilu ni. Gẹgẹ bi mo ti sọ fun ọ ni oru ana, o pẹ ti mo ti ngburo rẹ nitori ati aja ati ẹran a mã wi nipa tirẹ pe, 'Ọlọgbọn ni Irinkerindo iṣe'. Idi rẹ̀ ti mo fi dupẹ lọwọ rẹ fun ọrọ ti o sọ ni eyi, afõresunìṣe kun inu aiye, nwọn dabi paramọlẹ lãrin awọn ọmọ enia. Njẹ iwọ mọ pe ẹniti o wà ninu idãmu owo ti a ya l'owo tun le pada ki o wipe a ya on nitori a jẹ amùsùwà ni! Sibẹ iru awọn wọnni pọ ninu aiye sũ. Nwọn dabi okuta kọ̀bìtì si oju ọna awọn ero ẹhin. Nwọn ti ba iwaju jẹ, awọn ẹniti o ba ti ba wọn pade lẹ̀kan ko ni ifẹ ran awọn ẹlomiran lọwọ mọ. Ṣugbọn iyanju mi ni eyi pe, ki á má ti tori ẹni buburu huwa buburu, nitori bi a ba wipe ki á bẹ igi a le bẹ enia, bi a ba wipe ki a fi õre ṣiṣe silẹ patapata, a le da awọn ọmọluwabi loro. Kini kan ṣa ni, a ko gbọdọ mã ṣõre bi omugọ, ki a mã so ẹwọn gõlu mọ ẹlẹdẹ lọrun, ẹniti o ba mọ iyi wura ni ki á mã ta wura wa fun. Ọrọ pupọ, irọ l'o nmu wa, ọrọ mi kò ni gùn gbọ̃rọ, mo dupẹ lọwọ rẹ nitori o mõre ṣugbọn ko ti isi nkan ti mo ṣe fun ọ rara, bi a ba fi ọ we ogunlọgọ awọn ẹlomiran ti nwọn ti de sakani ile wa."

Lẹhin eyi, ọkunrin nã wa bẹrẹsi sọ itan igbesi aiye rẹ̀ gãn o dahun o ni:

"Emi ni Irinkerindo ti ngbe Ile Alarinkiri. Ibatan ni emi ati Akara-õgun ti o tọ ọ wa ni ijọsi jẹ, ẹgbẹ l'a si jọ jẹ pẹlu. Baba mi ni ẹniti njẹ Oyindaiyepọ ti ó duro gẹgẹ bi Mọ́gàjí ni Ile Alarinkiri. Oyindaiyepọ wa lọ fẹ iya mi ti orukọ rẹ̀ njẹ Ẹni-aiye ti nwọn bi si ile awọn Akara-õgun. Akoko igbati awọn Akara-õgun fi nmura ati lọ si Oke Langbodo gãn ni baba





mi ran mi lọ si idalẹ kan ni ijọsi. Inu iya mi, Ẹni-aiye, ko dun si ọran nã nitori o fẹ ki nba awọn ero Oke Langbodo lọ, emi nã pãpã si fẹ bẹ̃ pẹlu. Ṣugbọn niwọn bi o ti jẹ pe baba mi fẹ wipe dandan ki nlọ si ibiti on ran mi, ko si ohun ti emi ati iya mi le ṣe. Aburo mi kan bayi ti o lọ si idalẹ ti ko fẹ wa sile mọ ni baba mi ni ki nlọ mu wa. Aburo mi yi, ki iṣe ọmọ iya mi, aburo baba mi obinrin ni o bi i, o si jẹ ọmọ lile.

Nigbati mo mã kuro ni ile, baba mi pe mi si yãra, nigbati mo si de ọhun tan o ni ki nsunmọ on mo si sunmọ ọ, lẹhin eyi o fi ọwọ kọ mi lọrun o si bẹrẹsi ọrọ isọ o ni:

"Ọmọ mi, Irinkerindo, mo fẹ sọ fun ọ loni pe ko si ẹni nã ninu aiye yi ti o fẹran ọmọ rẹ̀ ju bi mo ti fẹran rẹ lọ. Idi rẹ̀ ti nko si ti ifi fẹ pe ki o ba awọn ẹgbẹ rẹ lọ si Oke Langbodo yi pin si ọna meji: lọna kini, ọran aburo rẹ yi wà lọkan mi, nko fẹ ki ọmọ nã lọ ṣe bayi sọ ori ara rẹ̀ nù si ilu onilu, lọna keji, mo fẹ ki oju iwọ pãpã tubọ là si i: nitori ẹniti o ngbe aba oko, ọgbọn abà oko nikan ni yio ni; ẹniti ngbe ileto, ọgbọn ileto ni yio ni, ṣugbọn ẹniti o ba nlakaka lati de ibi pupọ ni ile aiye yi, oju oluwarẹ̀ yio la ju ti ọpọlọpọ lọ.

"'Ṣugbọn, ọmọ mi, ọran idalẹ ṣoro. Ẹniti o ba ti bẹrẹ irinajo oluwarẹ ti gbe apo iya kọ ejika, nitori ẹniti o ti nsun lori ibusun nla lè di ẹniti nhanrun lori ilẹ pẹpẹ, ẹniti o ti nfi ẹdọ ẹran jẹun le di ẹniti ko ri nkan wa gãri mu, bẹ̃ni ẹniti ko to aburo oluwarẹ le mã bu u ki o mã ṣẹ epe fun u. Bi iwọ ba bẹrẹsi ri nkan wọnyi, ronu rẹ dãdã, kọ iwọsi ti o ba tọ ni kikọ̀, si rọju gba eyiti o ba yẹ lati gba mọra.

"'Maṣe gbagbe ohun gbogbo ti mo ba ọ sọ wọnyi, iwọ ọmọ mi. Ki Ọlọrun má kọ àtúnrí, bi Olodumare ko ba kọ àtúnrí, a jẹ pe ng o tun fi oju mi ri ọ, ṣugbọn iku ki ida ọjọ, bẹ̃ni àrùn ki ida oṣu, Ẹlẹda l'o mọ ọjọ ati sun ẹni. A ki imọ, bi o ba de ti o ba si gbọ pe mo ti ku, maṣe ba ara jẹ, ṣu ọ̀ṣùká pataki ki o gbe ẹru mi bi ọkunrin. Ni gbogbo igbesi aiye rẹ ti ó ba si kù, tọju iwa rẹ, maṣe ba ojukokoro ṣe ajọpin, nitori olojukokoro ti lu ofin kẹwa Olodumare, on dabi ọmuti enia ti o ṣẹ̀ṣẹ̀ fẹ lọ mọ ilu Eko, ti o wọ reluwe, nigbati o de ibiti a npe ni Iddo, o sọkalẹ, o kọju si Eko, nigbati o si de ori afa ti o wa lori omi ọsa, o nwo ihin wo ọhun, ko fi oju si ibiti o nlọ, nigbẹhin, o duro, o yọju

lori afa, o tun ṣe, o gun ori irin giga ti nwọn fi mu afa duro, o nrẹrin, lẹhin nã, o dorikodo, o nfì dùgbẹ̀, ibiti o ti nfì dùgbẹ̀, ọwọ ja, o takiti, o di inu odo, ẹja ri i, ẹja gbe e mì, ẹranko nla tun ri ẹja, ẹranko gbe ẹja mì, ejo nla miran tun ri ẹranko, ejo nla tun gbe ẹranko mì, ẹja inu okun wa ba ẹja inu ọsa ṣire, o ri ejo, o tun gbe ejo mì, nigbati o pada de inu okun, o ti sanra, ẹja nla miran tun ri i, o tun gbe e mì, asẹhinwa asẹhinbọ, awọn apẹja ri ẹja nla yi, nwọn pa a, nwọn wọ ọ si oke, nwọn mu ọbẹ nwọn nla inu ẹja. Bẹ̃ni nwọn la inu ẹja ti nwọn ba ẹja, ti nwọn tun la inu ẹja ti nwọn ba ejo, ti nwọn la inu ejo ti nwọn ba ẹranko, ti nwọn tun la inu ẹranko ti nwọn ba ẹja, ti nwọn la inu ẹja ti nwọn ba ọmuti enia ti o ku giliti bi olojukokoro ti o nlepa ohun ini ọmọnikeji rẹ̀ ti o sare titi ti o fi oju gun igi. Ṣọra nipa ojukokoro, mã sa fun u, o buru ju majele lọ.

"'Ọrọ mi ko ni ju bayi lọ, mo fi ọ si abẹ itọju Ọlọrun Ọba, Ẹlẹda rẹ yio mã ba ọ gbe ẹru rẹ, Olodumare yio tãri bilisi siwaju, Ọlọrun yio gba ọ lọwọ awọn abinuku ẹni, bi o si ti nlọ, o ko ni ba eleṣu rin, o ko ni ba akotirẹ̀batẹni ṣe ajọpin, Olodumare yio gba ọ lọwọ agbako, o ko ni bọ si ọwọ tẹmbẹlẹkun, o ko ni pade ijamba, o ko si ni rin lọjọ ti ebi npa ọna lailai. O digba o, o digba o, o digba, ọmọ mi.'

"Bayi ni baba mi sọ, nigbati o si dakẹ emi nã bẹrẹsi ọrọ isọ mo ni: 'A! Baba mi, bi ẹ ti sọrọ yi, a dẹruba mi lọpọlọpọ, bi iku ba jẹ alãnu ko gbọdọ ti iṣe bẹ̃ mu yin lọ. Gbogbo aiye yin, emi l'ẹ fi sìn. Gbogbo ohun ini yin, emi l'ẹ fi tọju, ko si si nkan t'o kù ni ode aiye yi ti ẹ ko fi kẹ mi. Amodi mi ijọsi nkọ!—Ọna wo ni mba fi wa lode aiye loni bi ko ba si ẹnyin? A! Amodi nla ti o nfẹ pa mi!—Ti otutu npa mi, ti õgun nbò mi, ti ara nro mi, ti ara nta mi, ti ara ngbona, ti ara ndùn mi, igba aiya mi ri gelete, inu mi ri ringindin, ẹrẹkẹ mi ri jekete, ẽgun aiya mi ri kẽrẹ, ori mi ri palagun, egungun iha mi han ketekete, iṣan ara mi ri wọ́gọwọ̀gọ bi gbongbo oju ọna, oju mi ri kùọ̀kuọ bi elẽri aṣọ téru, irun ori mi dabi irun ara aja elẽku, ẹsẹ mi ri tĩnrin bi ṣaṣara ọwọ̀, ara mi nwariri bi àlòkù mọto, mo nmí fúkéfúkẹ́ bi rọ́bà kẹkẹ, ara mi si nfunfun bi ara aboyun obinrin: ibanujẹ de ba awọn ara ile wa, nwọn nsa kiri gọ́lọ́gọ́lọ́





bi ẹja inu omi, awọn enia wa dorikodo bi imọ ọpẹ, iya mi nrin ka tironutironu, ile wa si dakẹ minimimi bi ọganjọ oru.

"'Ẹnyin, baba mi, ẹ bẹrẹsi wadi ọran yi, nitori ẹ ko mo iru aisan ti o dede kọlu mi, ẹ ko mọ iru ohun ti o de ba mi, yala oke-ilẹ ni, warapa ni, ibà ni, lakuregbe ni, ọlọ-inu ni, aran-aiya ni, ẹhin didun ni, tabi igbẹ-ọrin ni—gbogbo iwọnyi ko ye yin, afi igbati o wu Olodumare ti o fi onişegun tõtọ han yin ni mo to di ẹniti nṣire kiri.

"'Kini emi ha ti iṣe fun yin, ẹ jọwọ ẹ maṣe ronu iku, baba mi; ẹ jẹki nṣiṣẹ ki ndi ẹniti nl'owo lọwọ, ki nra agbádá nla ki ngbe e fun yin, ki nfi dandogo pataki bọ̀-yin lọ́rùn, ki nṣe fun yin bi ọmọ ti iṣe fun baba. Eleyi ni ọrọ ti mo le sọ fun yin, mo ṣetan lati lọ si ibiti ẹ ran mi, ẹ jẹki nlọ sile ki nlọ mã mura.'"

"Bayi ni mo sọ ti mo lọ si ọdọ iya mi. Igbati o di ọjọ keji mo ko ẹru mi mo kọju si ọna, mo nlọ.

"Fun odidi ọjọ mẹta ti mo ti kuro ni ile, ọkan mi ko kuro lara baba mi, ṣugbọn nigbati o ṣe diẹ, mo bẹrẹsi mu ọkan kuro ni ile mo nronu ibiti mo nlọ. Nko le ka ohun ti oju mi ri tan ki nto de ọhun nitori nko iti irin iru ìrìn bẹ̃ ri. Oju ọna nã jẹ oju ọna ti awọn apania ti mã ndọdẹ enia kiri ṣugbọn nko nikan rin rara, bi nko si ti nikan rin yi nã, a bọ si ọwọ awọn ọlọṣa to igba mẹta ki a to de ọhun. Ni akoko kan bayi, mejila ni awọn ọlọṣa pa ninu wa.

"Mo si dupẹ lọwọ Ọlọrun pe asẹhinwa asẹhinbọ rẹ̀ mo de ibiti aburo mi wà lẹhin oṣu kẹta ti mo ti kuro ni ile. Ṣugbọn bi mo ti de ọhun ni ẹniti mo wa lọ ti gbọ pe mo de, o si sa ba oko lọ, mo wa aburo mi titi nko ri i, nigbati o pẹ ṣa mo gburo rẹ̀ pe o wà l'oko, mo si fi enia ṣe enia nwọn mu mi lọ. Ọlọrun si wa ba mi ṣe e wipe ni ọjọ ti mo de oko nã ẹhin ni ó kọ sí mi, ki ó si to yi oju pada mo ti sare si i, mo di i mu. Nigbati o wo oju mi, o dun u, ṣugbọn sibẹsibẹ ifẹ ti o ni si mi ko kuro nibẹ, o yipada, o dọbalẹ o si ki mi dãdã. Emi nã ki i, mo sọ oriki si i, lẹhin nã o mu mi lọ si ibiti o ngbe o si wa onjẹ fun mi.

"Lalẹ ni mo to sọ ohun ti mo ba wa pataki fun u, mo si ba a wi pupọ pe ohun ti o ṣe ko dara. Ki a má sa ba ọrọ nã gun lọ titi, nigbati o to bi oṣu kan ti mo ti de ilu nã, emi ati aburo mi mura, o di ile.

"Oṣu keje ti mo ti kuro ni ile ni mo to pada de, lọjọ kẹta ti baba mi si ku ni mo de ile, bi nwọn ti sin oku rẹ̀ tan gãn ni.

"Iwọ ọrẹ mi, diẹ l'o kù ki iku baba mi sọ mi di wèrè; fun odidi ọsẹ mẹta nko mọ bi aiye ni mo wà bi ọrun ni. Nigbati o di kutukutu ọjọ kan mo lọ si iboji baba mi mo sọkun si i mo ke lohùn arò mo ni: 'Aiye-mi ni yi, aiye mi ni yi, baba mi, mo fi ọ silẹ bi enia, mo ba ọ bi ilẹpa! Baba mi ti mo fi silẹ ti yipada o di iboji! Iku ti mu akikanju lọ! Iku ti mu enia pataki lọ! Alabaro mi ko si mọ, tani mbá fi inu han bi ko ṣe baba mi! Tani ha kù bi alafẹhinti mi! Tani kù bi oludamọran! Tani ki nwọle tọ̀ ki njẹun! Tani ki nwọle tọ̀ ki nsọrọ ẹ̀dùn ọkan! Tani ki nba sọrọ lọganjọ oru! A! Iku! Iwọ adaniloro ẹda! Kini mo fi ṣe ọ! Lọ kuro lọdọ mi, lọ kuro lọdọ mi, iwọ ni ọta ogunlọgọ ohun ẹlẹmi ti Olodumare sọ lọjọ̀ si ori ilẹ aiye. Igbẹhin eweko inu igbo, iku ni; igbẹhin ejo afaiyafa, iku ni; igbẹhin ẹiyẹ oju ọrun, iku ni; igbẹhin awọn ẹranko ẹlẹsẹ mẹrin iku si ni pẹlu. Ọlọkan lile ẹda ni iku jẹ, ko ni ãnu ẹnikẹni, bẽni ki ipinnu ki o bojuwo ẹhin lẹ̃kan. Ki a sọkun ki oju fọ ko kan iku, ki a gb'ara ṣanlẹ titi ko yi i lọkanpada, ki a wọ aṣọ dudu ko ṣe nkan fun u. Iku ko nãni ẹbọ, kò bikita fun ṣigidi, bẽni onde ati oruka ko ṣe e ni nkan. A! Iku, kini iwọ o ha ṣe ni ọjọ igbẹhin rẹ! Mura, pa ilẹ mọ, mã duro de idajọ, ni igbẹhin aiye, awọn ẹda alaye yio mu ọ wa si idajọ niwaju Olodumare, ni ọjọ nã, eṣinṣin lasan yio ro ẹjọ mọ-ọ, ẽra yio jẹri gbè ọ lẹsẹ, o kò si ni ni ọrẹ lãrin enia ati ẹranko: nitori iwọ ti ba onirũru iṣẹ ọwọ Olodumare jẹ, iwọ ti ge aiye awọn ẹja kuru, o ti ba igbadun awọn kokoro jẹ, ekolo alaimọkan ko si kuro lọwọ paṣan rẹ. Ọpọlọ ati akere, igbin ati ijapa, àdán ati owiwi, ekute ati okete, ojola ati ajanaku—gbogbo wọnyi ni yio gbógun ti ọ ni ọjọ ibẹwo rẹ. A! Iku, iwọ ẹda alailãnu, mo fi ọ silẹ fun Ọlọrun Ọba.'

"Bayi ni mo wi ni temi ti mo kuro ni iboji baba mi ti mo wa si ile. Nwọn ṣe oku nã dãdã, nitori bi o tilẹ jẹ pe nko fi oju ri oku nã ki nwọn to sin i, sibẹ awọn aburo mi ti o wà ni ile wi fun mi pe awọn ọmọlẹ̀bí mu aṣọ wa ni oriṣiriṣi lati fi dì i, ati wipe nwọn pa ọpọlọpọ ẹran. Emi pãpã ba ọpọlọpọ agbọ̀n ẹkọ ni ile, nwon si lu ilu fun ọjọ pupọ ni ile wa. Emi nã ṣe oku bi





ipa mi ti mọ, ṣugbọn bi mo ti nnawo to, ọkan mi ko kuro lara baba mi, bi mo ba si nrẹrin loju bayi, ibanujẹ a bo isalẹ inu mi bi ikũkũ. Baba mi ti pin ogún silẹ ki ó to ku, nitorinã ko si ariyanjiyan nipa eyini. Nwọn iba si ṣu iya mi l'ópó fun ọkan ninu awọn ara ile baba mi, ṣugbọn iya mi kọ̀, ó ni on kò fẹ ẹnikẹni mọ lode aiye, on o joko sinu ile baba mi ki on mã tọju wa. Emi ni akọbi, igbati baba mi si ku yi ni mo to wa mọ pe ohun ti awọn agba nfi ara gbà ki iṣe kekere, ati pe ẹru aṣãju wuwo o ju irin. Ohun gbogbo ti nko ṣe ri ni mo di ẹniti nṣe, eyiti kò kàn mi ri di temi pataki, mo di ẹniti npari ija fun awọn ara ile wa.

"Lati ọjọ ti ọfọ nla yi ti ṣẹ̀ mi, nko ye la ala ri baba mi, afi bi ẹni pe ó wà laiye ni, eyiti ó si wa jọ mi loju julọ patapata ni pe igbati mo ba ri i loju ala nko ni ranti pe ó ti ku mọ, a si dabi ẹni pe o wà lãye ni. Lọjọ ti mo ba ti la ala bayi, jiji ti mo ba ji, ẹkun ni mo mã nsun.

"Lọjọ kan, mo ri i o wọ ẹwu agbada daradara kan bayi, ara rẹ̀ si dabi ara ọmọ kekere, ó lẹwa gidigidi. Ó gbe digi kan bayi lọwọ, o si fi han mi o ni ki nwo inu rẹ̀. Nigbati mo wo o, mo ri oju ọna kan ti ó tobi, ti ó gbõro ti ó si ndan. Apa ọtun ati apa osi dabi ẹni pe idẹ ni nwọn fi si eti ọna nã lọ. Ni ipẹkun ọna nã, mo ri ile kan ti ó lẹwa, ti ó dabi ãfin ọba. Ṣugbọn ki enia to de ibi didara yi, oluwarẹ̀ yio kọja ọna buruku kan, mo si ri awọn ẹranko buburu gbogbo ti nwọn duro si eti ọna buruku nã, ti nwọn nṣọ ọ. Nigbati mo wo digi nã dãdã, baba mi bi mi ohun ti mo ri, mo si sọ fun u. Lẹhinnã o dahun ó ni, 'Aiye rẹ ni iwọ nwò nì, iya yio jẹ ọ ni iṣãju, ayọ jẹ tirẹ nigbẹhin, ṣugbọn bi iwọ ba ba ara jẹ lakoko iyà, yio ṣoro ki ayọ igbẹhin to de ọwọ rẹ.'

"Bayi ni baba mi sọ loju ala fun mi, Oyindaiyepọ ọkunrin, bi ó si ti wi bẹ̃ tan ni mo taji.

"Nigbati o di ọjọ kan, lẹhin oku baba mi, bi mo ti nmura ti mo nfẹ lọ si ode kan bayi ni mo dede ri iranṣẹ ọba ti ó wọle wa ba mi. Lẹhin ti a si ki ara wa tan ni o wi fun mi pe ọba ni ó ranṣẹ pe ki nwa fi oju kan on ni werewere. Eleyi yà mi lẹnu nitori nki ide ile ọba tẹlẹ bẽni ko si si ọran ti mo da, ṣugbọn baba mi a ti mã lọ si ãfin lẹ̀kọkan ki o to di pe titan de ba a,

nitori on ati ọba ilu wa ti nṣe ọrẹ tẹlẹ ki o to di pe onitọhun gun ori oye.

"Mo wi fun onişẹ ti ọba ran wa wipe ki o mã lọ siwaju dè mi, ati pe mo nbọ lẹhin rẹ̀, lẹhin eyi, mo yi aṣọ mi pada: mo wọ awọtẹlẹ mi fẹlẹfẹlẹ si isalẹ, mo wa wọ tógò mi tuntun ti mo şẹ̀şẹ̀ da le e, lẹhin eyini ni mo gbe ẹwu agbádá ẹtù baba mi mo kì i bọ ọrun, mo si mu şokoto ẹtù pẹlu mo wọ̀ ọ, mo wa de fila abetiaja sãnyan mi kan bayi mo ta a ha-nha. Mo şẹ̀şẹ̀ şe oruka gõlu kan, mo fi i si ọwọ osi mi, si ọmọ ika ti o duro si ipo kẹrin si atanpako mi. Lẹhinnã, iya mi wa mu iborun àrán rẹ̀ tuntun o sọ ọ le ejika mi, mo si tun wa mu salubata kekere kan bayi ti a fi awọ ejo şe mo kì i bọ ẹsẹ, mo so agogo ti mo rà ti idalẹ bọ mọ ọrun ọwọ mi osi, mo mu ọpa kan ti mo şẹ̀şẹ̀ ra bayi lọwọ, mo si wa mu ọmọde kan lẹhin, mo kọ ori si ile ọba, mo nlọ.

"Bi mo ti nrin lọ inu emi nã ndun, yiyẹ ti nwọn si nyẹ mi si, afi bi ẹni pe mo ju bayi lọ. Ogunlọgọ awọn ti ki iti ibikita fun mi ni nwọn ndọbalẹ ti nwọn nwipe, 'k'ẽ pẹ, k'ẽ pẹ,' ti emi nã si nki wọn, ti mo nşe 'õku, õku,' bi agbalagba. Omiran ninu awọn obinrin ile wa ti nwọn nta ọja lode a wa siwaju mi nwọn a kunlẹ nwọn a tu gele wọn, nwọn a mã fi ori balẹ nwọn a mã yẹ mi si.

"Iyalẹnu ni o jẹ fun mi nigbati mo yọ si ọba ti o si dide lori itẹ lẹsẹkannã ti o wọ inu iyãra rẹ̀. Şugbọn nigbati o wa pẹ diẹ ti ó pada de ni awọn ijoye rẹ̀ wi fun mi pe yiyọ ti mo yọ ni inu ẹwu ẹtu ti mo wọ̀, mo jọ baba mi tobẽ ti ori ọba fi wú, ati wipe nitori eyini ni ọba şe wọle ti o lọ sọkun nitori ko gbọdọ sọkun loju gbangba.

"Nigbati ó de ti o joko lori itẹ, emi wà lokẽre. Nigbati o joko tan, o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni:

" 'Sunmọhin, iwọ Irinkerindo ọmọ mi.' Mo sunmọ iwaju itẹ, mo dọbalẹ, ọba si tun nba ọrọ rẹ̀ lọ o ni,

" 'Irinkerindo, emi ni mo pe ọ. O ku inawo oku baba rẹ, o ku asẹhinde, ki Ọlọrun jẹki ẹhin rẹ̀ dara. Ó yà mi lẹnu bi baba rẹ ti şe şe bẽ ku, nitori ni kete igbati ó fi mã ku, ó wa si ọdọ mi, ara rẹ̀ si le dãdã nigbanã, a tilẹ sọrọ ti o pọ, afi igbati o si to ọjọ marun lẹhin rẹ̀, ti nwọn mu ọ̀fọ̀ rẹ̀ wa ba mi!—Iku





rẹ̀ nã dun mi lọpọlọpọ, nitori Oyindaiyepọ ko jẹ bẽ lara mi, ki ifii ọran mi şire, bi ó ti wà ni ile rẹ̀ nì, ki işẹ ki ó má wa bẹ̀ mi wo ni ãfin yi lẽkọkan. Tori iwọnyi nã ni mo si şe pe iwọ ọmọ rẹ̀, Irinkerindo, loni, wipe ki o má jẹki orukọ ile yin bajẹ o. Ni ọjọ ti baba rẹ wa sihin gbẹhin, ó kó, ó rò, bi ó ti jẹ pe o nşe si on, ti o nhuwa ọmọ dãdã, ti o fẹran on de gongo ti on nã si fẹran rẹ. Ó wi fun mi pẹlu bi ó ti jẹ pe gbogbo õgun ti on mọ ni on ti fi kọ ọ, ati pe gbogbo ọgbọn inu on, on ko fi ọkan pamọ fun ọ, ó si tun wi fun mi pẹlu bi ó ti şe jẹ ohun ẹ̀dùn ọkan rẹ, iwọ Irinkerindo, pe o kò le ba awọn Akara-õgun lọ si Oke Langbodo ti nwọn lọ laipẹ yi, nitori ibiti on ran ọ, ati pe nigbati o ba ti ibẹ de, ọkan rẹ yio tubọ gbo lati şe bi awọn ẹgbẹ rẹ ti nşe. Nisisiyi wayi, Irinkerindo; ọran miran ti de ilẹ o, bẽni bi baba rẹ ba wa laiye, on ni mba ran ni işẹ nã ki o lọ şe e fun mi. Eleyi nã ni yio si fi han gbogbo enia iru ọmọ ti iwọ o jẹ, yala bi o ba ni le to ẹru baba rẹ gbe, tabi bẽ kọ, bẽni Oyindaiyepọ baba rẹ ki işe kekere ọkunrin.

" 'Işẹ ti mo nfẹ ran ọ nã ni yi, mo fẹ ki o wa şe aşãju awọn ọdẹ miran, ki ẹ wa lọ si Oke Ironu, ti mbẹ ninu Igbo Elégbèje, ki ẹ wa lọ ka eso igi ironu fun mi wa. Igi Ironu ni o fun ilu nã l'orukọ, abami igi ni igi ironu, baba mi si ti nsọrọ rẹ fun mi ki o to di pe titan de ba a, ti emi wa gun ori oye. Bi enia ba gbin igi nã si orisun omi ni ilu kilu ẹnikẹni ti o ba mu ninu omi ibẹ yio di ọlọgbọn patapata. Bẽni kini gbongbo igbega ode aiye patapata? Mo şe bi ironu ni. Aironu ni nmu ki enia jale, ti nmu ki enia şeke, ti nmu ki enia şãta ọmọnikeji, ti nmu ki enia rẹ ọmọnikeji jẹ, ironu ni o wà ni idi ẹrọ mọto, on ni gbongbo reluwe, on ni ọmọ enia fi nfo loju ọrun, ironu ni pataki ohun ija onişegun, on ni o wà ni idi egbõgi, paripari gbogbo rẹ̀, bi enia ba wà ti o wipe ko si nkan ti Olodumare le şe, alaironu ni. Agbara ironu pọ, on ni iyatọ ti o wa lãrin awọn ọmọ enia ati awọn ọmọ ẹranko. Nitorinã, Irinkerindo, iwọ ọmọ Oyindaiyepọ, ba mi wa eso igi ironu lọ.'

"Bayi ni ọba sọ, mo si fetisilẹ mo gbọ gbogbo ọrọ nã tan patapata, nigbati ó si pari ọrọ rẹ, mo dahun mo ni:

" 'Kabiyesi, ki ade pẹ lori, ki bata pẹ lẹsẹ, mo gbọ gbogbo bi ẹ ti wi, ori ni alakoso ara, ọba si ni olori ilu, ẹnyin ni olori

awa. Bi ọwọ ko si ti gbọdọ ṣe afojudi si ori, ti ẹsẹ ko gbọdọ wipe on ko si labẹ ãbo rẹ ni nko to ẹniti nṣe orikunkun si yin. Kabiyesi, mo fẹ ki ẹ mọ lati oni lọ pe ki iṣe ẹniti o ba fẹ iya ẹni nikan ni baba ẹni, ki iṣe ẹniti o ba si jẹ iyawo baba ẹni nikan ni ijẹ iya, baba ẹni le jẹ ọkan, iya ẹni le jẹ ọkan, baba ẹni le jẹ meji iya ẹni si le jẹ meji, nwọn le ju meji lọ pẹlu bẹni a ko ṣai ri ẹlomiran ninu ode aiye ti baba rẹ kò ku ṣugbọn sibẹ ti o duro bi alainibaba, nitori wipe, ibã ṣe ara ila õrun, ibã ṣe ara iwọ õrun, ẹniti o ba fẹran ẹni ni baba ẹni. Kabiyesi, lõtọ ni baba mi ko si ninu aiye mọ, ki ọba ki o pẹ, mo mọ pe ẹ to baba fun mi.

" 'Nipa ti ibiti ẹ ni ki nlọ, ng o lọ. Igbati mo ba wipe nko lọ, tani ki nwipe o bi mi! Mo fẹ ki t'aja t'ẹran jakejado ilẹ yi loni mu u kuro lọkan wọn bi nwọn ba ni ero wipe nitori Oyindaiyepọ ku, ina ile wa ku, ati nitori Oyindaiyepọ ṣe alaisi, oṣupa ile wa wọ okunkun, irọ mà ni o, kabiyesi, irọ mà ni o, bi Oyindaiyepọ ba ku Oyindaiyepọ mà ṣì mbẹ o. Bata ti baba mi fi silẹ, mo ti pinnu ati fi ẹsẹ mi si i, ọna ti o ti ntọ ri, mo ti pinnu ati mã tọ ọ; bẽni mo si ti ṣu oṣuka bàmbà silẹ ti ng o fi gbe ẹru baba mi. A! O mà ṣe o, Oyindaiyepọ ṣe bẽ o lọ, baba mi ṣe gudugudu meje fun mi, ó ṣe gudugudu meje fun mi, ó ṣe gudugudu meje fun mi, Oyindaiyepọ baba mi, baba mi, baba mi.

" 'Kabiyesi, mo fẹ ki ẹ ṣe kini kan fun mi. Mo fẹ ki ẹ yan ẹnikan pataki le mi ki a yi gbogbo agbegbe lọ ki a kede irinajo si Oke Ironu ti mbẹ ninu Igbo Elegbeje. O yẹ ki a si tete lọ pẹlu, nitori ọpọlọpọ awọn ọdẹ ni nwọn ti ba Akara-õgun lọ. Lẹhin eleyi pẹlu, mo fẹ ki ẹ yan awọn enia ṣà-nkò-ṣà-nkò ki ẹ ran wọn lọ si ọdọ awọn ọba alagbara ni ilẹ ibomiran gbogbo ki ẹ wi fun wọn nipa ọran irinajo nã ki nwọn ba ran awọn ọdẹ gbogbo jade. Bi ẹ ba ti ṣe wọnyi, inu mi o dun gidigidi nitori awọn ọdẹ ti nwọn ti fi ori pamọ yio gbe ori soke, awọn ti nwọn ti fi ori mulẹ ni ikọkọ ni a o wu jade. Igbati a ba ti ṣe iwọnyi tan eyiti o kù ko ni ju ki a da ọjọ lilọ wa. K'ẽ gbo k'ẽ tọ o.'

"Bayi ni mo sọ fun ọba, inu rẹ nã si dun si mi, o wò mi o bu si ẹrin o ni, 'A kàn nsọ pe Oyindaiyepọ lagbara ni, eleyi mã ṣe ju Oyindaiyepọ lọ.'





"Lẹhin eyi, ọba ni ki nwọn fun mi ni onjẹ nwọn si fun mi. Lẹhin nã o ni ki nwọn mu ọti jade nwọn ko igo meji jade, ọba pãpã ni o si nbu ọti nã, ki nmá fa ọrọ gùn lọ titi ṣa, a pari igo meji yi ki nto kuro ni ãfin, oju mi npọn ṣẽ emi nã ta fila mi ha-nha mo nta rá-ngọ́ rá-ngọ́ lọ.

"Jijade ti mo jade ṣe ni mo ri onilu ti o nrekọja lọ mo ba ni ki o mã lu ilu tẹle mi. O nlu ilu, emi nã si njo lọ. Awọn ọrẹ ati ojulumọ mi pẹlu awọn ibatan mi gbogbo ti nwọn gburo mi ni awọn tu jade ti nwọn dapọ mọ wa ti a jọ njo lọ, igbati mo si fi mã de ile, awọn enia pọ lọ bẽrẹ, mo nawo pupọ lọjọ yi, ọjọ idaraya ni.

"Nigbati o di ọjọ keje ni ọba ranṣẹ wa ti o ni on ti ri ẹniti on o fi le mi lọ si igberiko ati pe ki njẹki on mọ igbati yio dẹ mi lọrun ati lọ. Mo da ọjọ meje fun ọba.

"Nigbati ọjọ pe, emi ati iranṣẹ ọba mura, a yi agbegbe lọ. Bi a ti nti ilu de ilu ti ileto de ileto ni nwọn ngbà wa tọwọtẹsẹ tobẽ ti a ko fi ẹnu kan onjẹ ti a mu ti ile lọ titi a fi de. Irinajo wa nã si ni ere gidigidi.

Akoko yi ni a ri abami ẹda kan bayi mu bọ orukọ ẹniti njẹ Ìbẹ̀mbẹ́-olókùnrùn ti ile rẹ mbẹ ni ipàlàpálá okuta. Emi nikan ni o lọ si ibiti mo ti ri i. Nigbati a de ilu kan ti nwọn wi fun mi pe eti ibẹ ni ọkunrin nã ngbe, mo wa a lọ, emi nã si mura gidigidi ki nto lọ, nwọn fi ọna inu igbo ti o ngbe han mi, o jẹ oju ọna oko, nigbati mo si rin to bi wakati meji ẹniti o nṣe amọna mi fi ọna kekere kan han mi ti o yà ni apa osi bayi, o dabi ọna awọn ọdẹ, o ba inu igbo lọ. Lẹhin nã ni eleyini pada lẹhin mi ti o fi emi nikan silẹ ki nmã fi ori run inu igbo lọ. O kilọ fun mi ki o to lọ pe ki nṣọra lara abami ẹda nã nitori ki ó má ba pa mi jẹ nitori Ìbẹ̀mbẹ́-olókùnrùn ni o le jẹun ju gbogbo ẹda ti o mbẹ ni ori ilẹ aiye, on ni o si le mu omi ju gbogbo wọn lọ. Bi o ti wù ki o jẹun to ko ni yo bi o si mu omi odo gbẹ kò ni ni itẹlọrun, abami ẹda patapata gbã ni.

"Bayi ni itan rẹ lọ: ki o to kuro ni ode ọrun wa si aiye o ti lọ wọ ẹwu aiku ni ode ọran lai si aṣẹ Olodumare nibẹ, o ji i wọ ni, nigbati ẹda ti o wà ni ikawọ ẹwu aiku ko si ni ile orukọ ẹniti njẹ Ògódògo, bẽni o wa si ile aiye, bi o si tilẹ jẹ pe enia ni o bi i. sibẹ kò le ku mọ. Ṣugbọn igbati o tun de ile

aiye iwa rẹ̀ ko fi i silẹ. Ni iṣãju patapata, nigbati Olodumare ṣẹṣẹ da awọn ọmọ enia si ode aiye ti ẹ̀ṣẹ̀ ko iti isi, awọn ara ode ọrun a mã wa ba ara aiye ṣire nwọn a jọ mã ṣe ariya pọ̀ ni. Igbati o di ọjọ kan ti Ibẹmbẹ-olokunrun ṣe ipade nla kan ti o pe ara aiye ati ara ọrun wa jẹun, nitori ẹran ti o ri ko to, o pa arẹmọkunrin rẹ̀ o din i ni ata, nitori ọti kò si to, o pa arẹmọbinrin rẹ̀ o rọ ẹjẹ rẹ̀ sinu igo, ṣugbọn nigbati awọn ara ode ọrun de, nwọn mọ ohun ti o ti ṣe nwọn ba ṣẹ epe fun u pe titi ọjọ ironupiwada rẹ̀, bi ó ti wù ki o jẹun to kò ni yo mọ, bi o si mu omi odò gbẹ ko ni ni itẹlọrun, idi rẹ̀ si ni yi ti o fi di abami ẹda bẽ̩ kalẹ lati ọjọ nã wa.

"Nigbati mo ba a, ibantẹ nikan ni o san mọ ibadi, oku agbọnrin meji ni mo si ba niwaju rẹ̀ ti o njẹ wọn. Igbati mo de eti ọdọ rẹ̀ mo pe ògèdè si i ki inu rẹ̀ ba lè rọ̀ si mi, lẹhin nã mo ni: 'Ìbẹ̀mbẹ́-olókùnrùn o ku iṣẹ o'—ko tilẹ wo apa ọdọ mi, onjẹ ti wọ̀ ọ lara ṣe ni o tẹ ori mọ onjẹ koko, emi nã si mu sũru diẹ si i. Igbati mo ri i pe o jẹ odidi kan tan mo pe e ni ẽ̩keji: 'Ìbèmbẹ́-olókùnrùn o ku iṣẹ o'—on nã wa wo apa ọdọ mi o fi imu da mi lohun o ni, 'hõ', o tun bẹrẹsi jẹ agbọnrin keji lọ. Igbati o pari agbọnrin keji wayi ni o to wa wò mi dãdã ti o dahun ti o wipe: 'Kil'o nwa?' Emi nã si fesi mo ni, 'Iwọ ni mo nwa, iwọ ni mo tọ wa gãn, ọba ilu mi l'o si ni ki nlọ pe ọ wa, nitori ki a ba jọ lọ si irinajo kan. Ni irinajo yi, a o de ilu kan ni ibiti awọn ẹranko ngbe ti o jẹ ilu wọn gãn, ibiti iwọ o ti mã ri to ãɗọta agbọnrin fun onjẹ ãrọ, ọgọta ìmàdò fun onjẹ ọsan, ati ẽdẹgbẹta kọlọkọlọ fun onjẹ alẹ. Eyini ọkan; lọna keji, a o lọ si Oke Ironu ti mbẹ ninu Igbo Elegbeje ko si si aniani pe bi a ba ti le ka ọkan ninu eso igi ironu jẹ ọna ati wò ọ ninu aisan jẹunjẹun yi ko ni ṣai ye ni, oñun ti mo ba wa ni yi, Ibẹmbẹ-olokunrun, ọkunrin, o ku jijẹ o ku mimu.

"Nko wi ju bayi lọ. Were ti ẹda yi ti gburo onjẹ di dide l'o dide ti o tẹle mi ti a nko rẹirẹi lọ, bẽ̩ nã l'o si nba wa kiri titi a fi pada de ilu wa. Igbati mo fi mã de ile, iya mi tun ti ku."

Bayi ni alejo mi sọ itan ara rẹ̀, igbati o si fi mã sọ ọ de ibiti a de yi, ilẹ nṣu, mo ba damọran pe ki a fi iyoku silẹ di ọjọ keji ki a to tun mã ba ọrọ wa lọ.






Ibẹmbẹ-olokunrun o ku iṣẹ o.

# IBẸRẸ IRINAJO SI OKE IRONU TI MBẸ NINU IGBO ELEGBEJE

Ni owurọ ọjọ keji, ko pẹ pupọ ti mo lọ ki alejo wa yi tan ti nwọn fi wi fun mi pe onjẹ ti ṣetan, gbogbo wa lọ si tabili, a jẹun.

Iyalẹnu l'o jẹ fun mi pe bi o tilẹ ti jẹ pe nko sọ fun pupọ ninu awọn ọrẹ mi nipa ọkunrin nã to wọnni, sibẹ ogunlọgọ awọn enia l'o ti gbọ nipa ọkunrin nã, ki o si to di pe a jẹun ãrọ tan lọjọ nã awọn enia ti rọ́ de ile wa.

Bi a ti jẹun tan ni mo ko awọn ohun ikọwe jade ti mo bẹrẹ iṣẹ, on nã si bẹrẹsi ọrọ isọ o ni:

"Ẹnyin janmọ̃, mo ki yin ẹ ku ijoko o. Inu mi dun pupọ bi mo ti ri yin yi. Dajudaju, pupọ ninu yin ni ko mọ mi tẹlẹ ri, bi nko ba si ni purọ, ẹnyin nã ṣajeji si mi. Loru ijẹta mọju ana ni mo de si ihin, ati igbati mo ti de ni a si ti bẹrẹ iṣẹ, iṣẹ l'a fi gbogbo ana ṣe, a ṣiṣẹ titi ilẹ fi ṣu ni, eyi ko si fun ni l'aye ati jade rara, bi ko ba si bẽ ni, à ba ti fi ẹsẹ ba pupọ ninu ile yin. Ẹniti o ba ri ọrẹ mi yi, o yẹ ki oluwarẹ̀ ki i dãdã, ọmọluwabi ni. Lati ijẹta ti mo ti de sihin l'o ti bẹrẹsi nawo fun mi, on ati iyawo rẹ̀ ko tilẹ jẹki nmọ pe mo kuro ni ile rara, nitorinã mo fẹ ki ẹ ba mi dupẹ lọwọ wọn dãdã."

Bayi ni ọkunrin nã sọ, awọn alejo wọnni si dupẹ lọwọ mi, lẹhin nã o tun nba ọrọ rẹ̀ lọ o ni:

"Mo ti sọ lana bi o ti jẹ pe ọba ilu wa ran mi ni iṣẹ wipe ki nṣe olori awọn ọdẹ pataki ti nwọn nlọ si ilu pataki kan ti orukọ rẹ̀ njẹ Oke Ironu nibiti nwọn o ti ka eso ironu lori igi ironu ninu Igbo Elegbeje. Oke Ironu mbẹ leti odi ọrun. Mo wi lana pẹlu bi o ti jẹ pe emi ati iranṣẹ ọba yí gbogbo agbegbe lọ ti a nwa awọn enia pataki kiri, mo si tun wi pẹlu bi a ti ṣe ri abami ẹdą kan mu bọ orukọ ẹniti njẹ Ìbẹ̀mbẹ́-olókùnrùn ti o jẹ ẹniti o lè jẹun julọ lori ilẹ aiye. Mo fẹ ki a mã ba itan nã lọ.

"Ki iṣe Ibẹmbẹ-olokunrun nikan ni a ri mu bọ̀. Ọkunrin kan bayi ba wa bọ̀ ti orukọ rẹ̀ njẹ Kùmọ́dìran, bẽni enia pataki ni, on jẹ ẹnikan ti iṣẹda tirẹ̀ yatọ gbã, bi enia kò ba lu u ni





kumọ dãdã lẹhin ọrun ara rẹ̀ ki ile. Ọran dandan gãn si ni pe bi o ba ti ji ni kutukutu owurọ, ẹnikan nilati na a ni kumọ mẹfa lẹhin ọrun, ki o nã a ni mẹfa ni ibadi, ki o si kan a ni ẹ̀ṣẹ́ mẹfa ni igba aiya ki o to jẹun. Bi ko ba si bẽ, ara Kumọdiran ko ni le lọjọ nã, a ni ori nfọ on, a ni inu nrun on a si bẹrẹsi ṣe bi arugbo kiri.

"Awọn obi rẹ̀ l'o kuku jẹki o ri bẽ, itan ọkunrin nã yio si fi han yin ohun ti o jẹki iṣẹda tirẹ̀ kuku yatọ tobẽ.

"Ni aiye atijọ, awọn ẹranko a mã sọ ara wọn di enia, nwọn a si mã wa si ọja lati ra onjẹ, nwọn a bọ àwọ̀ ara tiwọn silẹ, nwọn a bẹ̀rẹsi tọrọ ẹ̀yà ara enia kiri lọwọ awọn iwin inu igbo ti ẹya ara wọn dabi ti enia, nwọn a mã tọrọ l'oriṣiriṣi ni, nwọn a gba apa lọwọ ẹnikan, nwọn a gba ẹsẹ lọwọ ẹni keji, nwọn a gba ori lọwọ ẹni kẹta, igbati nwọn ba tò wọnyi jọ nwọn a dabi enia gãn.

"Nigbati o di ọjọ kan, erin wa gẹgẹ bi ọkunrin, ẹ̀kun si wa gẹgẹ bi obinrin, nwọn ri ara wọn, nwọn fẹ ara wọn. Erin ti o jẹ ọkunrin gba ile kan o nsanwo oṣõṣu le e lori ibẹ ni awọn mejeji si ti mã npade lọjọ mẹsanmẹsan ọjọ ọja. Adehun wọn kò yẹ̀ fun odidi ọdun kan gbako, ekini ko mọ pe ẹranko ni ekeji, o ṣebi enia ni. Ki a má sa fa a gun lọ titi, ẹkun loyun fun erin, nwọn bi Kumọdiran. O jẹ arẹwa enia, o ga, o sigbọnlẹ, o si lagbara tobẽ ti nko iti igbọ pe ẹnikan fi ẹhin rẹ̀ balẹ ninu ijakadi ri. Ọwọ rẹ̀ gùn, nitori baba rẹ̀ ni o fi ọwọ jọ ṣugbọn yiyara iya rẹ̀ l'o mu, lõtọ ẹniti o bi ni l'ã jọ, Kumọdiran jọ awọn obi rẹ̀ gãn. O jẹ ẹniti o mọ ọdẹ iṣe pupọ nitori bi o ti nfi ibọn pa ẹran nã ni o nfi ọwọ pa, ti o tun nfi ẹsẹ pa, nitori ẹsẹ rẹ̀ tobi diẹ o fi jọ baba rẹ̀, bẽ ni ọrọ ọkunrin nã ri.

"Ẹni kẹta ti o tun jẹ pataki ti a ri mu bọ ni ẹniti orukọ rẹ̀ njẹ Aiyédèrú-ẹ̀dá ti o ngbe ileto kan lẹba ilu wa, on ni o fẹ obinrin kan bayi ti o njẹ Inudimeji ti imã gbe ile Ìbẹ̀rùparapọ̀. Ni akoko ti a de ileto yi ni ina kan bẹ silẹ ninu ile Ìbẹ̀rùparapọ̀ ti o jo ile nã kanlẹ ko. Sibẹ Aiyédèrú-ẹ̀dá ṣe itọju wa tobẽ ti nko iti iri ẹniti o tọju enia tobẽ ri. Lọjọ ti a de ibẹ gãn, apoti ọti kan l'o wa gbe fun ni, o si fi malũ meji le e. Lọjọ keji, o fi ẹru iṣu mejilã ranṣẹ pẹlu ṣago ẹmu ogidi mẹwa, o gbe apo idọ̀họ gãri kan, apo elubọ meji, garawa epo mẹjọ pẹlu apo iyọ

nla kan. Olowo ni ọkunrin nã o si ni to ile meji si ileto yi, ọkan ninu ile nã l'o ngbe nigbati a ba a, gbogbo nkan ti o nfi ranṣẹ si wa wọnni ọkunrin kan bayi ti orukọ rẹ njẹ Ojuaiyedùn l'o ntẹle wọn wa, on ni olori awọn ẹniti nṣiṣẹ labẹ Aiyédèrú-ẹ̀dá.

"Inawo ti Aiyédèrú-ẹ̀dá ṣe fun wa ni akoko yi pọ tobẽ o si jọ̀ mi loju ti mo fi pinnu pe on ni yio jẹ igba keji mi nigbati a bạ nlọ si Oke Ironu ninu Igbo Elegbeje.

"Ẹ maṣe gbagbe pe lẹhin ti ọba ran awa ki a wa awọn alagbara gbogbo lọ si agbegbe ilu wa o tun ran awọn miran lọ si ọna ti o jina si ọdọ awọn ọba nla gbogbo. Igbati awọn wọnyi mã pada de, onirũru enia ni o tẹle wọn: awọn ọdẹ ti nwọn ti nṣe ọdẹ ki iya mi to wọle ọkọ, awọn arìn-'rìn-àjò ti nwọn ti rin ti oju wọn ti da ṣakaṣaka, awọn arugbo ti oju wọn ti ri abami nkan ninu aiye, awọn amoye ti ọgbọn ti fi agbari wọn ṣe ibujoko, awọn jagunjagun ati alagbara gbogbo, adahunṣe ati ẹlẹbọlõgun, gbajumọ ati bõkini, awọn ọmọ talaka ati awọn ọmọ olowo—gbogbo wọn ni nwọn pe si ilu wa: akoko pataki ni.

"Nigbati gbogbo wa pada de patapata lati ibiti ọba ran wa ni o sọ fun mi pe ki a da ọjọ lilọ wa a si da itadogun. Nigbati a da ọjọ tan bayi, ọba bẹrẹsi ṣe itọju mi ni onirũru ọna, o fun mi ni apo owo kan lati fi pese irinajo nã, mo di ẹniti nwọle ti njade ni ãfin ọba. Ọwọ epo ni araiye nba ni lá, nwọn ki iba ni la ọwọ ẹ̀jẹ̀, òṣì ni njẹ 'Tani mọ̀-ọ', owo ni njẹ 'Mo ba ọ tan'. Nigbati awọn ara ilu wa ti ri i pe mo nṣe bi ire bi ire mo ndi enia pataki ni nwọn ti bẹrẹsi wọ́ wa si ile mi ti nwọn nṣe ọrẹ mi, awọn ibatan wa gbogbo ti a si ti sọnu ri ni ọran yi wu jade ti nwọn fi ara wọn han bi ara ile mi, bi awọn ẹgbọn mi ti nbi si i, ni awọn aburo mi nlé si i, akoko nã ni mo si mọ bi baba nla baba mi ti ṣe ba iya nla iya ẹlomiran tan. Ni akoko yi, nko wa õgun ti mo fi nri i, nwọn nmu u wa ba mi ni: mo ni oruka idẹ ati ti irin, mo ni oruka òjé ati ti bàbà, bẽni onirũru onde ni mbẹ̀ ni ìbàdí mi: nitori mo fi awọ erin ṣe onde, mo fi ti ẹkùn ṣe, mo si fi ti ijimere ṣe pẹlu. Mo ṣe ọmọ owú ni agbẹdẹ mo si ṣe ẹ̀mú mo rẹ wọn ni õgun mo so wọn mọ idi mi, mo mu iwo agbanrere mo sọ ọ di apoti mo ko õgun kun inu rẹ̀ bamubamu. Ọṣẹ õgun mi ko ni iye, agunmu kò ṣẽ ka, mo





sín gbẹrẹ si ori ahọn, mo sin si iho idi, mo sin si pari ẹrẹkẹ, mo sin si atẹlẹwọ, mo sin si atẹlẹsẹ, mo sin si ori ọmu, mo sin si ori dodo, mo sin si iho imu, mo si sin si oju ila atẹlẹwọ mi, bẽni ọtatelegbeje gbẹrẹ ni mbẹ ni atari mi. Mo ṣe ètùtù titi mo pa ẹṣin mẹfa, mo fi igbin mẹfa bọ ori, mo fi akukọ mẹfa bọ ṣìgìdì, mo pa aguntan mẹfa ni agbala, ọgọta ewurẹ ni mo si fi ṣe sarã si ikorita. Mo tubọ mura mo kọ ifa mọ ifa, mo mọ pataki ninu awọn odù, mo mọ itan aiyebaiye, mo mọ ijinlẹ ògèdè, bẽni ẹmi mi fẹrẹ bọ nibiti mo ti njẹ atãre. Iyãra kan pataki ni mo fi fun õgun ninu ile wa, ọmọkọmọ ko gbọdọ ta firi lagbegbe ibẹ, afi ọmọ ti o ba ro ọkà tan laiye ti o fẹ lọ fi ọbẹ̀ jẹ ẹ ni ọrun. Nitori tírà wà ni oke àjà iyãra mi, onirũru ni gbogbo wọn, ọsanyin olohun kẹlẹkẹlẹ wà lãrin awọn ṣigidi, àdó ati atọ́ ko gba õgun mi mọ, mo ko ogunlọgọ sinu ikoko iyãra mi—awọn nkan wọnyi ti pe si mi lọdọ ki ọjọ lilọ wa to pe.

"Nigbati ọjọ lilọ wa ku ọjọ meje ọba paṣẹ ki nwọn lu agogo yi ilu ka pe ki gbogbo awọn ara ilu wa si ãrin ọja ni ọjọ ti a o ba lọ ki a ba dagbere fun ara wa.

"Nigbati ọjọ lilọ pe gọngọ sọ ni ilu wa, ki ilẹ to mọ ni gbogbo enia ti nwọ jade ti nwọn si ti duro si ãrin ọja dè wa.

"Gẹgẹ bi eto ti a ti ṣe tẹlẹ, gbogbo awọn ọdẹ ti yio ba ni lọ si irinajo nã yio kọ wa si ile mi, ibẹ ni a o ti ko ẹsẹ lọ si ãrin ọja. Awọn ọdẹ ti ko ba ni lọ yio de ni kutukutu nwọn o to ara wọn ni ẹsẹsẹ lati ile mi de ãrin ọja nwọn o duro ni arãdọta ẹsẹ si ara wọn ni mejimeji ti nwọn kọju si ara wọn, ọkan ni apa ọtun ekeji ni apa osi oju ọna ti awa o mã gbà rin kọja lọ, bi a ba ti nde ọdọ ọkọkan ninu awọn ọdẹ wọnni, awọn meji ti nwọn kọju si ara wọn, nilati yinbọn si oju ọrun pọ̀ lẹkanṣoṣo.

"Igbati ọba ba de si ãrin ọja, a o gbọ ariwo ni ile mi, igbati a ba si gbọ ariwo ni awa nã yio to dide.

"Bi a ti ṣe eto yi nã ni a tẹle e, igbati ọba de ãrin ọja, a gbọ ariwo ni ile wa, awa ọdẹ si to ni ẹsẹ-'sẹ a tẹle ara wa ni ọgbõnran kan, a nlọ, gbogbo wa jẹ ãdọta. Igbati a dì mọra tan ti a jade, o nwu awọn ti ko fẹ lọ tẹlẹ ki nwọn ba ni lọ. Bi a ba ti de ọdọ awọn ọdẹ ti nwọn wà loju ọna wọnni, nwọn a yinbọn.

"Nigbati a de ãrin ọja, a lọ si ibiti nwọn ti pese silẹ fun wa.

'Nko ni le darukọ gbogbo wa bi a ti ṣe to lọ lẹṣẹṣẹ, ṣugbọn ng o darukọ ẹni mẹsan ninu wa.

"Emi ni mo duro si ipo kini.

"Ẹniti o duro tẹle mi ni Aiyédèrú-ẹ̀dá ti mo ti sọ itan rẹ̀ ṣãju.

"Ẹni kẹta ni ọkunrin kan bayi ti orukọ rẹ̀ njẹ Inulaiyewà ti o jẹ ẹniti o gbọn pupọ ti o si jẹ olokiki enia. Ki iṣe ara ilu wa ṣugbọn àna mi ni. On ni o fẹ ẹgbọn mi obinrin ti o jẹ iyekan baba mi. Ìdálẹ̀ ni ẹgbọn mi nã lọ ti nwọn fi ri ara wọn ti nwọn fẹ ara wọn, nitorinã a ti mã wa si Ile Alarinkiri tẹlẹ ri ki o to di pe ọran Igbo Elegbeje kanlẹ yi. Inulaiyewà jẹ ẹniti o mã nṣiṣẹ kakiri ẹhin odi oju rẹ̀ si ti ri nkan pupọ sẹhin, o ti gbe ọpọlọpọ ilu, o ti gbe ãrin onirũru enia, iya ti jẹ ẹ, ebi ti pa a, nwọn ti di rikiṣi mọ ọ, ó ti ṣaisan, ó ti joko lai ri aga, ó ti dubulẹ lori ilẹ pẹ̀pẹ̀, ongbẹ ti gbẹ ẹ lai ri omi, ó ti duro ni odidi ọjọ lai jẹun, ó ti rin ni on nikan loju ọna, ó ti sun lai ri aṣọ bora, otutu ti pa a, õrun ti pa a, o si ti ri ẹgbãgboje iwọsi ti enia nba pade lẹhin odi.

"Ẹni kẹrin ni ẹniti orukọ rẹ̀ njẹ Ewe-ẹ̀yẹ ti o jẹ babalawo pataki ni apa ila õrun. Olõgun bi Ewe-ẹ̀yẹ ko si afi bi a ba mã purọ tan ara ẹni jẹ, nitori ọdun mẹfa ni o gbe ninu igi iroko ti o nṣe babalawo fun awọn ẹmi buruku ti ngbe inu igi. Lẹhin eyini o joko sinu igbo fun odidi ọdun kan, nibẹ ni o si ti ri abami ijimere kan ti o fi onirũru ewe han a ti o si kọ ọ ni ilo wọn. Ewe-ẹ̀yẹ ni o na iwin de ibiti iwin ti npohunrere ẹkun, on ni o gba aṣọ lara oku ti ko tete lọ si ọrun, ti ó nyọ si awọn enia kiri, a mã gbọ ohun ẹiyẹ, a mã gbọ ti ẹranko, a si mã gbọ ọrọ ti igi nsọ si ara wọn. On ni o gbe iwin ni iyawo leti adagun omi, ti o ya owo lọwọ Ọsanyin, ti o gba ohun ọsin lọwọ Eṣu ti ngbe ikorita.

"Ẹni karun ni ọkunrin kan bayi ti orukọ rẹ̀ njẹ Oloju-májèlé ti ima gbe ehin erin kiri. Bi itan ọkunrin nã ti lọ ni yi. Baba rẹ̀, iwin ni; ṣugbọn iya rẹ̀, enia ni. Iya rẹ̀ jẹ arẹwa enia. Nigbati o wà ni wunndia ti ó lọ si oko lọdọ baba rẹ̀ ni ọjọ kan lakoko ọdun orò, bi ó ti nrin lọ ni ó dede gbọ ti oro nke bọ niwaju ti o si tun gbọ ti oro nke bọ lẹhin, ó ba sa wọ igbo ó nba inu igbo lọ, bi ó ba si ti ngburo orò ni ó tubọ nwọ inu igbo





si i, nitori ki ó má ba ri orò loju ọna. Nipa ṣiṣe bẽ, o ṣina sinu igbo, nitori orò ti nke ki iṣe oju lasan, awọn iwin ni nwọn mu orò jade. Ki a má sa fa a gùn lọ titi, ilẹ ṣu u sinu igbo. Ibiti o ti nkakiri ni on nikan ni ó ti ba iwin kan pade, ti o fi inu okuta ṣe ibugbe, ti o ni oju mẹrin, imu meji, ati enu meji, ti ó si ni iwo meji ti ó dabi ìwo agbanrere si àtàrí. Igbati iwin nã ri obinrin yi, kò ṣe e ni nkankan, ṣugbọn o mu u si ọdọ rẹ̀ ninu iho ó sọ ọ di iyawo. Ninu ṣiṣe bẽ ọmọbinrin nã loyun, ó bi Oloju-májèlé silẹ.

"Iwa iwin ati ti enia ko le ba ara ṣe dẽdẽ, asẹhinwa asehinbọ, tọkọtaya yi jà, ọkọ le aya jade. Ṣugbọn niwọnbi ọmọ ti nwọn bi ko ti ti idagba tobẽ, ko le fi iya rẹ̀ silẹ, nigbati obinrin nã si mã kuro ninu iho okuta nì baba ọmọ nã fi ehin erin kan ta ọmọ rẹ̀ lọrẹ, titobi ni ehin erin nã, o lu iho lati apa kan si apa keji, bi enia ba ti wo inu rẹ̀, ibikibi ti ó ba nfẹ ni ó le ri bi o ti wù ti ibẹ jina to.

"Ẹniti o duro si ipo kẹfa ni Kùmọ̀dìran ti mo ti sọrọ rẹ̀ ni iṣãju.

"Ẹniti o duro si ipo keje ni ọkunrin kan ti orukọ rẹ̀ njẹ Filasaiyepọ ti ó ngbe fila àràmọ̀dà kiri. Ọkunrin nã jẹ ibatan Olojumajele ni idi iya, ṣugbọn ọkan ninu awọn iwin pataki ni baba rẹ̀ iṣe nitori baba rẹ̀ ni aburo olokun ti iṣe alakoso omi, o si tun jẹ aburo Èsìdálẹ̀ ti o jẹ ijoye pataki ni ode ọrun. Ọrun Apãdi ni Filasaiyepọ dagba si nitori baba rẹ̀ ti fi i fun Eṣu ti iṣe ọba ibẹ ni kekere ki ọmọ nã má ba bajẹ, Eṣu si fi iya jẹ ẹ gidigidi, ibi ina ileru nla ni Eṣu fi si ki ó mã fẹ ina ni Ọrun Apãdi, eleyi si mu ki oju ọkunrin nã yipada ki ó di pupa, bẽ nã si ni ara rẹ̀ yipada ti o di dudu mọnamọna.

"Iyalẹnu ti ó wa ti idi ọmọ nã jade ni pe igbati o pẹ, apa Eṣu kò ka a mọ, bi Eṣu ba ran a ni iṣẹ a ṣe eyiti ó wù u, bi Eṣu ran a ki o yara wa sinu aiye ki ó da ija silẹ lãrin ọrẹ meji, a wa, a sọ wọn di ọrẹ ara wọn, igbati Eṣu ba nja ni Ọrun Apãdi a mã wãsu fun awọn ọmọ Eṣu. Asẹhinwa asẹhinbọ, Eṣu ka a si ẹni buruku, ó le e jade, igbati on nã nbọ, ó pade ọkan ninu awọn ẹmi ọdọ Olodumare lọna, igbati ó si kó ti o rò fun u, inu ẹmi nã dun o si fi fila kan ta a lọrẹ, ohunkohun ti ó ba nfẹ ni fila nã le ṣe fun u, nitori iwin mbẹ ninu fila nã, bi ó ba si ti sọrọ

si fila kẹlẹkẹlẹ, iwin a jade, ohunkohun ti ó ba wipe ki ó ṣe ni yio ṣe. Ṣugbọn Filasaiyepọ kuro ni Ọrun Apadi o wa sinu aiye o nṣiṣẹ ọdẹ, ibiti o si ti nṣe ọdẹ ka ni on ati Kumọdiran ti pade ti nwọn di ọrẹ ara wọn ipa Kumọdiran ni o si tọ̀ de Irinajo si Oke Ironu yi.

"Ẹni kẹjọ ni Ibẹmbẹ-olokunrun ti mo ti sọrọ rẹ̀ fun yin tẹlẹ.

"Ẹni kẹsan ni ọkunrin kan bayi ti nwọn npe ni Ìrèké ti o sọ ijo jijo di iṣẹ nla, ti o sọ orin kikọ di òwò pataki, ti o si fi fere rẹ̀ si ipo ọmọ. Iyekan ni Ireke ati Olohun—iyọ ti o ba Akara-õgun lọ si Oke Langbodo ni ijọsi, ọkunrin yi le jo ju òkòtó lọ, bẹ̃ni bi o ba fọn fere rẹ̀ ki teniatẹranko mã jo ni.

"Nisisiyi, ẹ ti gbọ orukọ awọn mẹsan pataki ninu wa, nko ni le darukọ awọn mọkanlelogoji ti o kù, nitori akoko nlọ, ṣugbọn gẹgẹ bi eto wa olukuluku ni o gbe ibọn lọwọ, afi Ireke nikan ni kò gbe ibọn, o nfọn fere rẹ̀ ki irinajo wa ba dabi ireke, ki o gbadun bi oyin.

"Nigbati awọn ọdẹ wọnni duro si apa kan, inu ọmọ enia dun. Nwọn to fi ṣe fọ́rífọ̀rí, nwọn duro bi alagbara, ọkan wọn balẹ bi ẹniti o gbẹkẹle Olodumare, nwọn le bi akọ okuta ninu ipinnu wọn, ọkan wọn ti hu iyẹ ó fò kuro ninu ile pẹlu ifasẹhin ibẹ, o lọ si ẹhin odi ọrun. Awọn ọmọ araiye wo wọn, nwọn bu si ẹrin, nwọn si kọ ọgbọn pataki nì lati ara wọn wipe, ko ti ninu iwa Olodumare pe ki o kọ ileri fun awọn ọmọ enia afi bi ohun ti awọn ọmọ enia ba fẹ ṣe, ba mã jẹ fun ipalara. Ẹniti o da aiye ti o tobi bàntà banta bi iru eyi, ti o fi enia jọba lori gbogbo rẹ̀, eleyini ti pari õre.

"Lẹhin ti ọba fi wa han awọn ara ilu tan ti o sọrọ rere nipa wa o ni bi mo ba fẹ sọrọ fun awọn enia gbogbo lorukọ awọn ẹlẹgbẹ mi, mo le sọ ọ.

"Nigbati ó wi bayi, emi nã ba bẹrẹsi ọrọ isọ, mo ni:

"'Mo ki gbogbo yin o, mo ki onile mo ki alejo, mo ki gbogbo enia patapata, mo ki yin l'orukọ awọn ẹgbẹ mi wọnyi, awọn arakunrin gbogbo ti nlọ si Oke Ironu, ti nlọ si inu Igbo Elegbejẹ̀. Awọn àgbà ti pa a l'owe pe, bi o ti wù ki ó pẹ to, ẹgbẹrun ọdun nbọ wa ku ọla, ọla nã pe loni wayi a si dupẹ lọwọ Ọlọrun Ọba. Ogboiya onișowo ni ijere, hilahilo ni oniyemeji imã ba kiri—ki Ọlọrun má ṣe wa ni onihilahilo enia. Ẹnyin ọmọ ilu mi, bi





ẹ ti ri wa yi, a ki iṣe omugọ. Bi ọmọde ba ṣubu, a wo iwaju, bi agbalagba ba ṣubu, a wo ẹhin. Lati ọjọ ti a ti nbọ ni ilẹ yi, njẹ bayi l'o yẹ ki ọgbọn wa mọ? Bi awọn baba nla wa ba ji ni isa oku loni kini iba jẹ ero wọn? Bi nwọn ti ṣe ngun iyan lati ẹgbẹta ọdun sẹhin l'a ṣe ngun u loni, bi nwọn ti ṣe nro ọka lati ẹ̃dẹgbẹfa oṣù l'a ṣe nro ọka, bi nwọn ti nkọ ọpẹ lati ibẹrẹ ọpẹ kikọ l'a ṣe nkọ ọpẹ, egbõgi ti nwọn ti mọ̀ a kò mọ ọ mọ, igberaga ti sọ ni di ero ẹhin: ọmọde nsọrọ ṣàkà si agbalagba, ọmọkunrin kò ka baba rẹ̀ si mọ, ọmọbinrin a ro aṣọ igberaga si igba aiya, a ni iya on ko jamọ nkankan—bẹ̃ni gbogbo iwọnyi, aironu ni.

"Idi rẹ̀ ni yi, ẹnyin enia wa, ti o fi di pe ẹ ri gbogbo wa ti a pinnu lọkan wa pe afi dandan bi a ti aiye lọ si ẹnu odi ọrun, si Oke Ironu ti mbẹ ninu Igbo Elegbeje, ilu ni Oke Ironu, o wà l'ẹnu odi ọrun, ṣugbọn inu rẹ̀ ni Igi Ironu wà eso eyiti o le ṣe ilẹ yi lõre. A nlọ nitori ẹgbẹrun iran ti mbọ lẹhin, a nlọ nitori gbogbo yin. Ko si nkan ti o dun mọ inu Olodumare rekọja pe ki enia mu ki aiye ọmọ ẹlomiran di dãdã, ko si nkan ti o dun mọ inu Olodumare bi ki enia jẹ, ki o fun ọmọnikeji ni aye ati jẹ, ki enia mu ki o si fun ọmọ ẹnikeji ni aye ati mu. Ẹniti ko fẹ ki ti ẹnikeji dara jẹ kiniun lãrin awọn ẹranko, aṣa idì larin ẹiyẹ, paramọlẹ lãrin ejo, bẹ̃ni orukọ awọn ẹranko wọnyi ti bajẹ lãrin igbẹ, sisa ni gbogbo ẹda alãye nsa fun wọn.

"'Mo si fẹ ki gbogbo yin mọ pe, bi a ti nlọ yi, a mọ nkan ti mbẹ niwaju wa, a mọ pe ẹranko buruku wà loju ọna, a mọ pe ejo oloro nduro dè wa, a mọ pe a nti ile lọ ba ebi, a nti ile lọ ba ongbẹ, a si nti ile lọ ba ẹgbẹrun iya ti yio jẹ ni. Ṣugbọn kini ẹmi enia? Ẹrọ ti o nlù kìkì lasan! Kini ero Ẹlẹda ti o fi fi ẹrọ yi fun ni? Njẹ Olodumare fun iwọ ati emi ni ẹmi fun ilo ara tiwa nikan ni?—ó tì o—ki iṣe bẹ̃ rara. Ẹmi mi wà fun ilo rẹ, ẹmi rẹ si wà fun ilo mi. Ẹlẹda ko ya awọn ọmọ araiye ni ipa, o ṣe wọn ni ọkanṣoṣo, agbajọ ọwọ ni a fi nsọ aiya. Pẹlu ayọ ni awa fi nlọ loni ki aiye ọmọ elomiran ba dara. Mo ti gbe inu aiye fun igbà diẹ, awọn ti mo ba l'aiye si ti sọ fun mi pe, bi ẹniti o nṣõre tilẹ fi ẹsẹ kọ, ko le ṣubu lailai. Ẹniti o nwa igbega fun ọmọnikeji ko ni si lãrin awọn ero ilẹ, ika ko lagbara niwaju olõtọ, aṣĩri onigberaga ki ibò,

iṣubu onigberaga dabi igbati ẹfũfu nla ba fẹ igi óko, ti ó wo iroko lulẹ, ti ó dá ẹka iroko, ti ewe iroko rẹ̀ silẹ, ti igi nã si gbẹ ; asẹhinwa asehinbọ olú nhù lara rẹ̀, o di ãbo fun okete, ibi iṣire awọn ẹiyẹ, ibugbe awọn ejo, ibiti alangba ti nle ara wọn kiri : nitori onigberaga kò fẹ ire ọmọ ẹlomiran, o nfẹ ki a ri on nikanṣoṣo.

" 'Ẹnyin enia wa, tiyin ni awọn ọdẹ ti ẹ nwọ wọnyi nfẹ, nwọn ko fẹ ti ara wọn nikanṣoṣo.

" 'Nitorinã, bi a ti nlọ yi, a ki yin o digboṣe, ẹ wò wa ki ẹ tun wa wò, nitori bọya eleyi ni o jẹ igbẹhin ti ẹ o ri ẹlomiran ninu wa. Njẹ mo ki yin lorukọ awọn ẹgbẹ mi, awọn akikanju enia ti nlọ si Oke Ironu, o digba o, bi iku ba pa wa, ki ẹ ṣe oku wa dãdã, ki ẹ ṣe oku wa bi oku ọlọla, ki ẹ ṣe ọ̀fọ̀ wa bi ọ̀fọ̀ enia pataki, ki ẹ má si ṣe jẹki nkan iwọsi de sakani ohun ini wa—o digba o.'

"Bayi ni mo sọrọ fun awọn ara ilu wa. Nigbati mo pari ọrọ mi, ọba nã tun sọrọ dãdã nipa wa, lẹhin eyi, a mura a nlọ.

"Ogunlọgọ enia l'o sìn wa si ọna, ipinya nã si ṣoro gidigidi : ẹlomiran npộṣé, ọpọlọpọ nmi ìmí ẹ̀dùn, oju awọn obinrin si dabi orisun omi ninu eyiti omije ti njade. Nwọn nfi gele ori wọn nu oju, omiran si nlo iborun lati fi nu õgun ti nṣan bi àgbàrá ojo kuro lara rẹ̀, ṣugbọn awọn agbalagba ko si ninu awọn ẹlẹkun wọnni, nwọn npe wa ni ọkõkan bi a ti nlọ, nwọn nfun wa ni imọran, nwọn nfi eti kò wa leti, nwọn si nsọ onirũru ọrọ aṣiri fun ni bi a ti nlọ.

"Nigbati o ṣe, gbogbo enia pada lẹhin wa, o ku awa ati Ọlọrun wa.

"Nigbati mo mọ pe gbogbo wọn ti lọ tan patapata, mo wi fun awọn ẹlẹgbẹ mi ki nwọn sọ kalẹ ki nwọn duro dè mi, lẹhin nã mo yà si inu igbo ni apa ọtun mi, nigbati mo de ọhun, mo ke pe Olodumare pe ki o jọwọ ṣe alatilẹhin wa bi a ti nlọ, mo ra ọwọ si oju ọrun mo si wi fun Olodumare pe, ṣigidi ko lagbara niwaju Ọlọrun, Anjọnnu kò gbọdọ fi ọwọ pa ida Ẹlẹda loju, ọgbọn ori ẹni ko to gba ni là lai fi ti Ọlọrun Ọba si i. Mo bẹ Ẹlẹda mi pe, bi mo ti jẹ aṣãju awọn ọdẹ wọnni, ki o jẹki njẹ aṣãju rere. Mo bẹ Olodumare ki o jẹki nmọ ipo mi lãrin awọn ọdẹ wọnni ki nle mã ṣe si olukuluku bi mo ti fẹ ki ó ṣe si mi.





**Ara igbo, ero ọna ẹ wa ba mi ra a o.**

"Bayi ni mo ṣe ti mo kó ọran mi le Ẹlẹda mi lọwọ, nitori ninu ohun gbogbo ti enia le fi ẹhin tì ni ode aiye ko si eyiti o lagbara bi Ẹlẹda ẹni.

"Nigbati mo pada de oju ọna olukuluku tun ẹrù dì dãdã, lẹhin nã a gbera a kọju si ọna wa.

"Oke Ironu jina pupọ, bi enia ba tilẹ de Igbo Elegbeje tan oluwarẹ tun nilati rin jina dãdã ki o to le de ilu nã, o sunmọ ode ọrun ju Oke Langbodo lọ nitori ọjọ mẹsan-mẹsan ni awọn ara ibẹ mã nna ọja pẹlu awọn ara ode ọrun. Odò kan bayi ni o pin ibẹ ni iya pẹlu ọrun, gbangba si ni awọn ti ngbe ibẹ mã nwo ohun ti awọn ara ọrun ba nṣe. Bi enia ba ntọ odò nã lọ si apa oke, nigbati oluwarẹ o ba fi rin to wakati mẹta yio kan odi nla kan ti o duro gẹgẹ bi ãla lãrin aiye on ọrun. Eti ibẹ ni ile Iku wà, ile Iku kò jina si ile Àrùn ti nṣe iyawo rẹ, bẹni eti ibẹ nã ni ile ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Baba—oni-rungbọn—yẹukẹ ẹniti ngbe ibi gegele okuta.

"Ọna Igbo Irunmalẹ ní ọna Igbo Elegbeje. Igbati enia ba si kọja igbo nã tan ti o fi ilu awọn ẹiyẹ ati ti ẹranko silẹ ni oluwarẹ o to ri ọna nã ti o ba apa ọtun lọ. Eyini ni pe oluwarẹ ko ni de orita ọna Oke Langbodo ki o to yà. Oluwarẹ yio kọja odò aró ṣugbọn ẽmeji ni oluwarẹ yio da odò ẹjẹ kọja.

"Apejuwe ti mo ṣe wọnyi yio fi han yin pe irinajo ti o lewu ni irinajo nã, ṣugbọn a ko ri iyọnu rara, oju wa ko si ri nkankan ju bẽ lọ titi a fi de Igbo Irunmalẹ, ṣugbọn nigbati a ti de ibẹ ni ijangbọn ti bẹrẹ. Nko le sọ awọn onirũru nkan abami ti a fi oju wa ri ninu igbo buruku nã tan, nitori awọn iwin ibẹ pọ gidigidi, bi a si ti nlọ ni nwọn nyọ si wa. Ṣugbọn mo nilati sọ nkankan ti a ri ni nkan bi agogo mẹsan owurọ ọjọ kan.

"Ṣẹ l'o dede ṣe ti a gbọ ti ẹnikan npolowo ọja ti ó ke lohùn rara bayi pe: 'Ara Igbo, ero ọna, ẹ wa ba mi ra a o, ọja mi pọ, owo kekere ni: warapa, pọnun mẹta; ṣọpọnna, pọnun meji; ẹ̀tẹ̀, pọnun mẹrin; wèrè, pọnun mẹfa; ori fifọ, ṣile mẹwa; ẹsẹ didun, ṣile mẹfa; õwo, ṣile kan; inu rirun, ṣile mẹwa; sobiya, pọnun kan; otutu, tọrọ; lakuregbe, pọnun kan; igbẹ ọ̀rìn, pọnun kan-abọ, ifọ̀n, sisi; kúrúnà, tọrọ; ikọ, pọnun kan; ibà, ṣile meje; oke ilẹ, pọnun meji; aràn, ṣile mẹ̀dogun etc., etc.'





"Bi ẹniti o npolowo ọja ẽmọ yi ti npa a ni a ngbọ ti awọn kan npe e, ti nwọn nra a lọwọ rẹ̀. Igbati o si ṣe, a ri on pãpã. Ọmọbinrin ni, ṣugbọn o lẹwa tobẽ ti nko ba iru rẹ̀ pade ri, o ro aṣọ funfun, o wọ ẹwu funfun, o di irun ori rẹ̀ winnikin-winnikin, o pupa fẽrẹ, ṣugbọn o ni iyẹ meji nla si apa bẽni nwọn da ẹwu ti o wọ̀ ni ọna ti iyẹ le fi ri aye yọ jade, ó wọ bata fadaka, ṣugbọn inu atẹ ti ó gbe ọja tita rẹ̀ gbogbo si, gõlu ni. Nigbati a ri i, ṣe ni nkan nã la gbogbo ara wa ja patapata tobẽ ti ẹnikẹni ko le gbe apa ti ẹnikẹni ko le gbe ẹsẹ ti a kò tilẹ le la ẹnu wa sọrọ jade lẹnu.

"Ṣugbọn on kọju si wa o ni, 'Ẹnyin ọmọ enia, emi ni iranṣẹ Olodumare, awọn ẹniti nra ọja mi wọnyi ni a npe ni alatunṣe. Ẹnyin ọmọ enia ni ẹ fa aisan ba ara yin ninu aiye, ṣugbọn, a! Ko si ẹda ti Ẹlẹda mi fẹran ti ó ta ẹnyin enia yọ, nitori Ẹlẹda ko le fi yin silẹ bẽ, igbati awọn alatunṣe wọnyi ba ra aisan ti mo nta, nwọn a mu u lọ, nwọn a lọ fi i ṣe igi, igbati aisan yi ba mu igi, nwọn a mu digi pẹlẹbẹ ti Olodumare fun wọn nwọn a fi wo kokoro ti o nda aisan nã silẹ, lẹhin eyi, nwọn a mu kokoro nã tọ Ọlọrun Ọba lọ. Igbati Ọlọrun ba ri i, Ọlọrun a kọ wọn ni ọna ati fi ba kokoro bẽ ja a si fun wọn ni aṣẹ ati lọ kọ o 'si igba aiya awọn ọmọ enia. Igbati Dokita pataki ba sun ni oru tabi babalawo àtàtà, awọn alatunṣe wọnyi a fo'lọ, nwọn a lọ kọ o si agbari wọn. Ṣugbọn, ó mà ṣe o, igbati awọn oniṣegun pataki wọnni ba ji, ti nwọn ronu ti nwọn ri idi aisan yi, nwọn kò ni imọ pe iṣẹ ọwọ Ẹlẹda awọn ni. Ibaṣepe ọmọ enia ki ifi oju idà wọn gbo' lẹ, diẹ ni Ẹlẹda pãpã iba fi ju wọn lọ, ipo ti ó fẹ fi wọn si pọ̀, o fẹran wọn.'

"Bi ó ti wi bayi tan, ó fò lọ.

"Igbati ó lọ tan ni ara wa to pada bọ̀ si ipo ti a to le sọrọ ti a to le rẹrin si ara wa. Ṣugbọn nigbati a gbọ ọrọ ti ẹda pataki nã sọ, o dun mọ ni ninu, ati pãpã ni ibẹrẹ irinajo wa, a mọ pe Olodumare ti o fẹran ọmọ enia to bi ó ti sọ yi, ko ni jẹ fi wa silẹ ni akoko iyọnu.

"Ọpọlọpọ awọn iwin ni a tun ba pade lẹhin eyi, igbati o tilẹ si ṣe, ẹru wọn ko ba ni mọ. A ko rin pupọ nigbati a ba ọkan pade ti o tilẹ di ọrẹ wa gidi, Iranlọwọ ni orukọ rẹ̀ njẹ on l'o wi fun wa pe on ni on yọ Akara-õgun ninu itimọle Agbako,

on l'o si fun wa ni imọran bi a o ti ṣe ti a ko fi ni de ilu awọn ẹiyẹ ni ibiti Ogongo ti nṣe ọba wọn. O wi fun wa pe bi nwọn ba ri ni nwọn o fi oju wa ri nkan nitori ohun ti awọn Akara-õgun ti ṣe si wọn. O fi ọna kan bayi han wa, on ni a si gbà ti a fi fi ilu awọn ẹiyẹ silẹ ni ibiti Ogongo ti nṣe ọba wọn.

"Ko pẹ ti iwin yi fi wa silẹ tan ti a pade awọn mẹta kan. Nigbati a pade ekini, kò ki wa; nigbati o si rekọja wa tan, o pòṣé. Nigbati a pade ekeji, o mi imi ẹdùn kanlẹ, o wò wa lati oke de isalẹ, o ṣe bi ẹni pe o npẹgan wa, nigbati a pade ẹkẹta o mọ wa loju, o poṣe, o si sọrọ, o ni, 'Awọn alakọri gbogbo'.

"Eyiti o tilẹ wa bu wa yi ko ga rara, o dabi kukute, nigbati mo si wo ẹnu rẹ bayi, o dabi ẹnu ọbọ, ehin meji kan ti o ká bayi ninu ehin rẹ mu ki ehin rẹ ri kafuru, afi bi ẹni pe nwọn ṣe ilẹkun si ẹnu abami ẹda nã. Igbati mo si ri bi awọn mẹtẹta ti ṣe, mo fesi fun eyiti o pe wa ni alakọri, mo ni, 'Ori rẹ alakọri, aiya rẹ alakọri, iwọ ẹbọra a bi ehin bi ehin okete yi.'

"Kini iwin nã gbọ bẹ̃ ṣe, o ni, 'Mo mọ tiyin bẹ̃, ẹnyin ọmọ enia. Ẹnyin onisọkusọ, onirokuro, onirinkurin, oniwakuwa, onijẹkujẹ, onimukumu, oniṣekuṣe, ọlọ̀tẹ̀, alabosi, alarãngbọ, alajagbula, ẹlẹṣẹ, eleke, oloṣi, ọlọṣa, ole, alaimọkan, alaimero, alailagbara, ẹnyin ko mọ pe awa ki iṣe ẹgbẹ yin?—Kini aiye ọmọ enia jasi?—Aiye ki nwọn mã purọ mọ ara wọn! Kini aiye ọmọ enia jasi?—Aiye ki nwọn mã tu aṣiri ara wọn! Kini aiye ọmọ enia jasi?—Aiye ki nwọn mã jowu ara wọn! Ẹniti o ba wà ni ipo giga nwọn ko jẹ ti i lẹhin, afi bi nwọn ja a tilẹ. Ẹniti o l'owo, awọn ọmọ enia ki iba a wa ọna bi owo nã ti ṣe mã bi si i, afi bi nwọn ti ṣe mã da oju ọwọ rẹ̀ de ilẹ. Ipo ti Olodumare fi ọmọ enia si, nwọn kò mọ ọ, ẹwu funfun ti Olodumare gbe bọ ọmọ enia lọrun, nwọn da epo pupa si i, Ẹlẹda fun wọn ni aṣọ iyi, ṣugbọn nwọn nrin ni ihõho—ẹnyin alaimõre, ẹnyin kò mọ pe okuta ti o ga ju yin ni igba ẹgbẹrun, ẹnyin a mã fọ ọ, igi ti o ga ju yin ni igba ãdọta ẹnyin a mã bẹ ẹ lulẹ, omi okun bi o ti tobi to nì, o wa ni ikawọ yin, ẹ nfi ọgbọn yin mu erin, ẹ nfi mu ẹkun, ẹ si fi nmu kiniun ọba ẹranko. Awa ti a ti mọ iwa yin ko bikita fun yin mọ, iwa burùku yin ko jẹki ẹ to nkankan loju wa.'





"Bayi ni iwin nã bu wa, bi o si ti nsọrọ ni mo nwo ehin rẹ kika, ti o mu ki ẹnu rẹ̀ ri foforo. Igbati o kọ nbu wa mo ti rò pe bi o ba ti pari bibu rẹ̀ ni a o bẹrẹ ija, ṣugbọn nigbati o fi mã pari ọrọ rẹ̀, ero ọkan mi ti pada nitori gbogbo ọrọ ti o sọ wọnni, ko fi wọn purọ mọ awọn ọmọ araiye, nitori eyi, igbati o pari ọrọ rẹ̀, mo ṣọ ori kọ, emi ati awọn ọrẹ mi dorikodo, a nrin kọ́-ndú-kọ́-ndú lọ.

"Ṣugbọn ọran awọn iwin yi di ija lãrin awa pãpã, bayi ni: Ṣe ni a fi awọn iwin nã silẹ tan ti ọkunrin kan bayi ti a npe ni Gọ̀-ngọ̀ṣú-tàkìtì ati ẹgbọn rẹ̀ ti njẹ Ìnàkí-g'orí-ìtẹ́ bẹrẹ gbe mi ti nwọn nbu mi pe nko sọrọ fun awọn iwin nã to bi o ti yẹ. Ọrọ nã dun mi pupọ, nitori nigbati a pade wọn, minimini ni gbogbo awọn ti a jọ nlọ dakẹ, ẹru nbà wọn, emi ti mo si tilẹ ṣe ọkunrin diẹ ti mo sọrọ, dipo ki nwọn yìn mi, bibu ni nwọn tun nbu mi mo ni, 'Njẹ iwọ, iwọ Gọngọṣutakiti, igbati a pade wọn, iwọ to ọ̀rọ̀ isọ? Hĩn?—Da mi lohun, mo ni iwọ yi to ọrọ isọ?—Ẹ kò ri ẹnu rẹ̀ bayi.' Nigbati mo wi bẹ̃, mo tilẹ ṣebi yio wipe on fẹ ba mi ja ni, afi igbati mo ri i ti o tun ṣokoto rẹ̀ ṣe dãdã, ṣokoto ọdẹ penpe ti o wọ̀ ti o pada ti o wipe on nlọ ba awọn iwin nã ja nitori eyiti mo wi. Gbogbo enia bẹ̀ ẹ́ titi ko fẹ gbọ. Ṣugbọn iba tilẹ gbọ o, bi kò ṣe ti ẹgbọn rẹ̀ Inaki-g'ori-itẹ ti o wipe afi bi o pada dandan. Ki a má sa fa ọrọ nã gun lọ titi, Gọngọṣutakiti pada, Inaki-g'ori-itẹ nã si tẹle e. Aṣé awọn iwin nã ko jina rara afi were ti nwọn pada ti a bẹrẹsi gbọ igbe Gọngọṣutakiti ti o nke, 'Ẹ gba mi o, ẹ wa gba mi o, o pa mi o, o yọ mi loju o etc., etc.'—ni a ba yara sare pada. Igbati a mã de ọhun awọn iwin ti yọ oju Gọngọṣutakiti, nwọn si de Inaki-g'ori-itẹ si ẹba ọna, nwọn fun u ni okùn danindanin ṣe ni o nṣẹju pàkò bi ejo ọka. Ṣe ni a bẹ awọn iwin titi ki nwọn to da wọn silẹ fun wa ṣugbọn idiwọ ni Gọngọṣutakiti wa dà fun ni, nitori ko riran mọ, ṣe ni a nfa a lọwọ kọja lọ lãrin itakun ati igi gbogbo ti o kun oju ọna wa.

"Igbẹhin ọran Gọngọṣutakiti buru pupọ, nitori igbati awọn iwin ti yọ ọ loju ni ọkan rẹ̀ ti kuro ninu aiye, nigbati o ṣe, ko jẹun mọ bẹ̃ni ko mu omi, asẹhinwa asehinbọ, o ṣubu lulẹ, a gba e, a fẹ oyi si i, ṣugbọn kò gbọ, igbati o ṣe, o pa oju de, a

fun ata si i loju, ko sọrọ, a pe ọfọ si i, ko da ni lohun mọ, o ti ku, ọkan rẹ ti lọ, ara rẹ ti tutu, iku de.

"Bayi ni a sọ ọkan pataki nù ninu wa, a si gbẹ iho, a sin i si i, a si sọkun a kãnu rẹ bi o ti yẹ. Inaki-g'ori-itẹ mu aṣọ dudu kekere, o san a mọ aṣọ rẹ, gẹgẹ bi àmì ọ̀fọ̀ Gọngọṣutakiti ti iṣe aburo rẹ.



## ALÀBÁPÀDÉ ẸLẸ́GBÁRA

"Lẹhin eyi, a kọju si ọna Igbo Elegbeje, a nlọ. A ko ri nkan abami kan ti o ṣe pataki fun ọjọ diẹ o to bi ọjọ mẹta ti a ti sin Gọngọṣutakiti ki o to di pe nkan miran tun de ba ni, bayi ni:

"Bi a ti de ibi kan bayi ti o tẹju diẹ ti a duro ti a jẹun tan ni a dede gbọ ariwo ogunlọgọ awọn ọmọde ni apa ọna ibiti a nlọ ti nwọn nke bọ lapa ọdọ wa. Aiya mi ja pupọ nitori igbe yi nitori mo nbẹru ki ó má ba jẹ iwin buruku ti okiki rẹ ti kan jakejado ode aiye ti a npe ni Ẹlẹgbara. Iwin buruku ni, bi ó ba nbọ awọn ọmọ rẹ ti a npe ni ọmọ Ẹlẹgbara ni o mã nṣaju ti nwọn mã nkede bibọ̀ rẹ fun gbogbo ohun alãye. Baba mi ti rohin iwin nã fun mi ri, ibeji ni pẹlu Eṣu, awọn mejeji si ni awọn ọmọ araiye nbọ ni ikorita. Nitorinã, igbati mo dede gbọ ariwo lãrin aginju yi, ẹru ba mi gidigidi.

"Lõtọ nã, bi mo ti ro o si l'o bọ si. Nigbati o ṣe, ti ariwo nã ntubọ sunmọ wa ni a bẹrẹsi gbọ ohun ti nwọn nwi. Nwọn nke bayi, 'A ki iwo o, a ki iwo o, ẹ yàgò fun u, ẹ yàgò fun u, mã rọra, mã wolẹ, kiyesi kòtò, kiyesi ipàntí, kiyesi gegele okuta. E : — : — : e, E : — : — — e, Ẹlẹgbara nbọ lọna o, ọ̀gọ lẹhin aṣiwere, kumọ lẹhin alaigbọn, ijangbọn lẹhin olori-kunkun, E : — : — : — e ! E : — : — : — e ! Ibõsi o, ibosi o, Ẹlẹgbara nbọ lọna o—a ki iwo o, ẹni wo o a ku, ẹni ko o ko jangbọn lọna, ẹni ri i, ri banujẹ ọsangangan, a ki iwo o ! A ki iwo o ! A ki iwo o : — : — : — etc.'

"Bayi ni a bẹrẹsi gbọ igbe nã ti o tubọ nsunmọ ọdọ wa. Were a yara di ẹru wa, bi a sı ti ndi i tan nã ni a wo iwaju ti awọn ọmọ Ẹlẹgbara yọ si wa.

"Ko si ẹniti ẹru kò ba ninu wa nigbati nwọn yọ, afi bi a ba mã purọ. Igbati nwọn si ti yọ ni a ti tú si igbo ti olukuluku sa pamọ bẹ́rẹ́bẹ́rẹ́, kẹkẹ ko gbọdọ gbin. Ẹlomiran sa wọ inu iho, omiran sa pamọ si abẹ ipanti, omiran sa gun ori igi, ọmọde ko le ri ẹru ki ẹru má ba a—Ẹlẹgbara kuro ni nkan yẹpẹrẹ.

"Ori apata nla kan bayi ni mo gun lọ ni temi. Lati ibẹ, mo le ri isalẹ kedere, awọn igi ati itakun ti o hu si ori apata nã si dãbobo mi, mo sa pamọ si ẹhin wọn, awọn duro bi àwọ̀n fun oju mi. Ibẹ ni mo wà ti mo ri awọn ọmọ Ẹlẹgbara ti nwọn nkọja lọ, mo ri wọn dãdã. Nwọn to ãdọta, nwọn ko si ga ju ẹsẹ bata mẹta mẹta lọ. Nwọn fi ẹfun on osùn sa oju, nwọn so iyẹ mọ ori, nwọn dudu mọnamọna. Nwọn ko wọ ẹwu bẽni nwọn ko wọ ṣokoto, ṣugbọn nwọn san yẹ̀rì mọ idi, ẹyọ owo si bo yẹ̀rì nã patapata. Nwọn to ilẹkẹ lati orunkun lọ si isalẹ igbati o kù diẹ ki nwọn to o de ọrun ẹsẹ, nwọn dawọ rẹ̀ duro, nwọn si wa mu ẹ̀gbà idẹ, nwọn to o yi ọrun ẹsẹ po, nwọn ge idẹ pẹlẹbẹ pẹlẹbẹ nwọn so o mọ ẹ̀gbà wọnni, eleyini si ndun woroworo bi nwọn ti nsare kọja lọ.

"Oju mi gbangba bayi ni nwọn ṣe nkọja, mo si duro mo nwo igbati Ẹlẹgbara pãpã mã tẹle wọn.

"Mo duro titi bi ẹni pe ki Ẹlẹgbara pãpã kọja, kò kọja, akoko gãn ti mo si bẹrẹsi ronu pe ko ni wa mọ njẹ ki nsufe pe awọn ẹgbẹ mi ni mo dede ri ti ilẹ nmì tìtì ti ogunlọgọ awọn ẹranko nsa kakiri, awọn ẹiyẹ pãpã kò fi ara balẹ mọ, nwọn nkigbe leralera, awọn ejo nsare gun igi nwọn tun nwọ́ lulẹ bẽni igbe awọn ọkẹrẹ gba agbegbe kankan. Igbati mo tun bẹrẹsi ri àmì wọnyi, mo tubọ mu ara duro, ki nmá ba wa lọ bọ si ọwọ Ẹlẹgbara.

"Nigbati o ṣe mo ri Ẹlẹgbara, o yọ lọkankan, o ba ni lẹru gidigidi. O gbe apo nla kan kọ ejika o si ko kumọ pupọ lọwọ. Irun ori rẹ̀ gùn, o dudu, o kun fun ipanti, òṣù kan ti o wa lãrin ori nã gùn, ó si nkan a ni idi bi o ti nrin lọ. Mo ri ogunlọgọ àdó ati ãkara igba ti ó tò mọra lati ibadi titi o fi de ẹsẹ koko, mo si ri ehin rẹ̀ ti o dabi ehin kiniun, bẽni iwin buruku yi nwo ọtun ti o nwo òsì ti o nwa wa kiri, nitori o ti gbõrun wa.

"Nigbati o ṣe ni mo ri Aiyedèrú-ẹ̀dá ti o sa jade ni abẹ itakun ti o sa pamọ si, nitori Ẹlẹgbara ju kùmọ̀ si ibẹ, Aiyederu-ẹda wa ṣebi o ri on ni. Igbati o sa jade yi ni Ẹlẹgbara pãpã to ri i, were o si ti di i mu, bi o si ti nfẹ pa a Aiyederu-ẹda kigbe o ni, 'Jọwọ ṣe mi jẹjẹ ki nba fi ibiti awọn yoku wà hàn ọ, nitori a pọ̀ ju bayi lọ.'

"Igbati o wi bayi, iwin nã kò pa a mọ, o ni ki o mã fi ibiti





a sa pamọ si han on, were Aiyederu-ẹda tọka si mi ni ibiti mo loṣo si ti mo fi awọn ewe boju lori apata.

"Nigbati iwin nã ri mi, o yara ju Aiye-deru-ẹda sinu apo o nsare bọ lọdọ mi. Bi o ti nbọ ni mo nronu ohun ti mo mã ṣe. Awọn itakun ati igbo dudu kan bayi wà ni isalẹ apata ni apa odikeji ibiti on nbạ gun oke bọ, mo si ti rọra yọ́ sọ kalẹ lẹhin ti nwọn ti ṣofofo mi fun u mo rá wọ abẹ itakun nã mo fi ara pamọ bẹ́rẹ́bẹ́rẹ́. On ngun oke bọ lori apata, ibiti ó si ti nfi iwọra sare bọ̀ kò mọ igbati mo fi rọra sọ kalẹ si odi keji. Ṣugbọn igbati o de ori apata ti ko tun ri mi mọ, o fura pe abẹ itakun nã ni mo wà, o ju kumọ rẹ̀ sibẹ, eyiti o kọ jù bà mi ni ipakọ ṣugbọn nko mira. O ju ekeji, eyi bà mi ni iwaju nkò sọrọ. Ẹkẹta ti ó jù bà mi ni gongo imu mi, mo rọra fi ọwọ ra imu mo dakẹ jẹjẹ. Ẹlẹgbara nã ba dawọ duro o tun nwo gbogbo agbegbe. Igbati ó pẹ ṣa, ọkan rẹ̀ sọ fun u pe ibẹ ni mo nilati wà, nitori ko ri mi ki njade lagbegbe ibẹ ó ba mu àdó kan jade, nigbati o sọ àdó si abẹ ìtí, àdó gbina, ina njo bọ lọdọ mi mo ba fò jade ti Ẹlẹgbẹra nã gbá tẹle mi, emi ti mo nsare iku mo nlọ ninu igbo gbururururururu. Ibiti o ti nle mi lọ apo ja lati ejika rẹ̀ silẹ, Aiyederu-ẹda sa jade. Igbati iwin nã ri eyi, o yipada o bẹrẹsi le Aiyedẹru-ẹda lọ emi nã tun nsa ba ọna temi lọ. Nigbati o ṣe, o ranti apo rẹ̀ ti o bọ, o fi awa mejeji silẹ o wa àpò rẹ̀ lọ.

"Mo gun ori igi kan lọ lẹhin igbati nko gburo rẹ̀ mọ. Ṣugbọn ko pẹ pupọ nã ti mo nwo Ẹlẹgbara ti o nwo ihin wo ọhun ti o npoṣe ti o nwa wa kiri, mo bẹrẹsi gbọ o nsọ bayi, 'A, awọn ọmọ enia ti nwọn ṣe ikùn bẹ̀mbẹ̀ bẹ̀mbẹ̀ wọnyi! A, nwọn ṣe bẽ nwọn lọ.'

"Bẽ ni iwin nã bẹrẹsi wi ti o nwọ igbo kiri ti o nkigbe pe ori ara rẹ̀, o nwo ihin, o nwo ọhun, o nwo oke, o nwo odò, o nwa wa kiri, olukuluku pa lọlọ, ẹnikẹni kò gbọdọ gbin, ẹni wukọ daràn, ẹni yi 'sẹ pada gbé, ẹnikẹni ko gbọdọ sọrọ pinkin, tani baba ti o bi oluwarẹ̀! Awọn ẹranko pãpã ko gbadun, igbo dakẹ bi ẹni pe ọ̀fọ̀ ṣẹ enia o ṣẹ ẹranko, emi nã rọra joko, mo ká gúlútú lori igi.

"Nigbati ó ṣe o nbọ lapa ọdọ mi, nigbati o si de ibẹ, o wo isalẹ, o wo abẹ ìtàkùn, o wo oke, ṣugbọn kò ri mi labẹ ewe o

si kọja si apa ẹhin mi, o lọ. Emi iba mọ ki nyara sọ kalẹ ki nwa ibomiran sa si! Nigbati o lọ siwaju diẹ o tun pada sẹhin nigbati o si nbọ lẹ̀keji nì, ti o tun gbe oju soke, A! O ri mi, alakọri ri mi, ijangbọn tun bẹrẹ, o bẹrẹsi mi igi mọ mi ni idi ki mba ja tilẹ, mo tilẹ kọ ro pe kò ri mi ni ati pe o kàn nmi igi lasan ni, igbati mo si rọra dakẹ ti nko sọrọ o dahun o ni, 'Wo ilẹ ki o wo ọrun, mo ti ri ọ, ọwọ ba iwọ ni tirẹ na etc., etc.'

"Nigbati o ti sọ bayi, mo mọ pe o ri mi, mo rọra dide lãrin ẹka igi ti mo sa pamọ si mo nbọ ni ilẹ, igbati o si kù diẹ ki nde ilẹ mo fò tagbaratagbara mo balẹ siwaju ibiti iwin nã wa, were ó ti fò tì mi, ṣugbọn ki o to kàn mi lara mo ti dide mo fi ire si i, ẹnyin ọrẹ mi, nkan de, Ẹlẹgbara nã gbe ere dà silẹ o, on nsare onjẹ, emi nsare iku, ọran di gbururururuuru! Mo gbọn ire bi ẹni ngbọn owu, iwin nã si nle mi lọ, a sare titi a fi de ibi iho titobi kan bayi, nigbati mo si de ibẹ mo kó si i, àṣẹ́ iho kiniun ni, igbati kiniun si ri mi ti mo nsa bọ o ṣebi Ẹlẹgbara ni mi, dipo ki ó ba mi ja, o sa jade, igbati o mã jade, o pade Ẹlẹgbara, ó ṣebi enia ni, o ba bẹrẹ ija pẹlu Ẹlẹgbara, nwọn bẹrẹ ija, ibiti nwọn ti nja, mo sa jade. Nko sa jina ju bẽ lọ ti iwin nã fi fa kiniun ya ti o tun nle mi lọ. Emi nã si mura mo fi ire si i. Nigbati o ṣe o le mi de ibi odo nla jijin kan, ibẹ l'o si ti ni ireti ati mu mi. Nigbati mo de eti odo yi, dipo ki nduro, ṣe ni mo bẹ si i, ti mo mõkun lọ, igbati mo si mã jade ãrin omi ni mo jade si mo ba fi iwẹ si i, mo wẹ̀ ja si odi keji odò. Ṣugbọn iwin nã kò le wẹ̀. Nitorina, nigbati o ri i pe mo wẹ de odi keji, ti emi wà ni apa ọhun ti on wà ni apa ihin, o poṣe, o ta ika si mi, o si ba tirẹ̀ lọ.

"Nigbati mo de odi keji yi, o rẹ̀ mi pupọ, iba ẹmi diẹ l'ó kù si mi ninu, mo sun silẹ gbalaha, mo nsimi. Ọlodumare mọ bi on ti iṣe itọju awọn ọmọ araiye, akoko nã gãn ni atẹgun didun kan bẹrẹsi fẹ, eleyi tù mi lara.

"Ibiti mo ti nsimi yi ni mo ti dede ri obinrin arẹwa kan ti ó yọ si mi. O lẹwa gãn ni, o wọ aṣọ dãdã, ara rẹ̀ tutu nini, o mọ tonitoni, ara rẹ̀ ndan bi ara ọmọ kekere, ehin rẹ̀ funfun bi aṣọ àlà, oju rẹ̀ gún bi oju oṣupa, ẹyinloju rẹ̀ mọlẹ kedere, ẹya ara rẹ̀ wà ni iwọntunwọnsi, nwọn ba ara ṣe dọgbadọgba, o ro aṣọ,





o we gele, o mu iborun lọwọ, o fi yẹri si eti, o fi oruka si ọwọ o si wọ salubata idẹ. Ẹnia dudu ni, o fi dudu wu ni.

"Nigbati obinrin nã ri mi, o wa si ọdọ mi, o rẹrin o si bẹrẹsi wadi bi mo ti rin ti on fi ri mi ni ibiti mo wà, mo ṣe alaye fun u dãdã, ṣugbọn bi o ti nsọrọ ni o nrẹrin musẹ si mi, ọrọ rẹ̀ wọnni si ṣe mi lõre lọpọlọpọ nitori aiye ti su mi ni akoko ti a nwi yi, ọkan mi si tilẹ ti nkabamọ pe kini ṣe ti nko jẹki Ẹlẹgbara kuku pa mi jẹ. Nigbati obinrin nã joko diẹ, o dide, o lọ bu omi tutu fun mi mu, omi nã tutu ju omi eti odò ti mo wà ni ìgbà mẹwa, nigbati ó si woye pe ãrẹ ti mu mi jù, o lọ mu õgun wa, õgun nã wà ninu igo kan bayi, igbati o si bu diẹ ninu õgun nã si inu galafi kan fun mi ti mo mu u, ṣe ni ara mi le gau, ọkan mi sọ ji.

"Igba yi ni mo to le sọrọ si obinrin nã dãdã, mo si bẽre bi o ti ṣe de ibẹ. O sọ fun mi pe enia ni iya on ṣugbọn ẹbọra l'o bi on fun, ati pe ẹbọra nã ni ọba agbegbe ibiti a wà ati pe ãfin baba on ko jina si eti omi ti on ti ri mi, o rọ̀ mi pe ki nwa lọ mọ ile on ki nki baba on ṣugbọn mo kọ̀ mo wi fun u pe mo sa nfẹ ki ọkan mi tubọ balẹ diẹ si i ni ki nwẹ̀ pada si odi keji odò ki nwa awọn ti a jọ nbọ lọ.

"Lẹhin eyi, obinrin nã bẽre bi mo ti ni iyawo mo si wi fun u pe nko iti ini, ati pe nkan bẽ ko tilẹ ti isi lọkan mi, ohun ti o leke ẹmi mi ko ju pe ki nṣe aṣãju awọn enia mi de Oke Ironu ti mbẹ ninu Igbo Elegbeje. Nigbati mo sọ bẽ, o rẹrin, ọkan mi si bẹrẹsi rò pe o nfẹ ki nfẹ on ni. Ki iṣe pe o fi ẹnu rẹ̀ sọ, emi rò bẽ ni. Nitori mo ti mọ pe iba diẹ ninu obinrin ni nwọn le fi ẹnu ara wọn sọ fun ọkunrin ki ó fẹ awọn, bi ifẹ tilẹ npa wọn bi ọti, ti o ntì wọn ka bi ẹniti oriṣa gùn, ati la ẹnu sọrọ nã jade a mã jẹ iṣoro.

"Ṣugbọn obinrin nã ṣe ãjo mi pupọ ọran rẹ̀ l'o si jẹki nmọ pe ifẹ a mã fa ifẹ yọ, nitori ṣãju akoko nã, nki ifẹran obinrin rara o si dabi ẹni pe ìṣẹ̀dá mi ni ki nmã korira wọn ṣugbọn nigbati mo mã fi eleyi silẹ, omi fẹrẹ bọ loju mi bẽni nko si tilẹ ni ọkan ati fẹ ẹ.

"On nã l'o ṣe ọna ti mo fi yọ lọwọ Ẹlẹgbara. Nibiti a ti nsọrọ, o bẽre ohun ti mo ro pe on le fi ran mi lọwọ mo si rohin iyọnu ti mo ti ba pade fun u. Lẹhin eyi, o pe aburo rẹ̀ ọkunrin.

Nigbati o de, o wi fun u pe ki o lọ gbe ọkọ̀ wa ki o tù mi kọja si apa keji odo, were nwọn ti mu ọkọ de, ati emi ati on si rekọja si odi keji lapa ibiti mo ti wa. Ki a to bọ si inu ọkọ o ti bẽre nipa Filasaiyepọ nitori o wipe ẹgbọn on ni, baba rẹ̀ jẹ aburo baba on awọn mejeji wa jẹ aburo Olokun ti iṣe alakoso omi. Ọ ni, baba on ti orukọ rẹ̀ njẹ Ajédùbúlẹ̀ ni ẹniti nwọn bi baba Filasaiyepọ lé, ni ile awọn. O ti mọ nipa fila ti Filasaiyepọ ngbe kiri. O wi fun mi pe o yẹ ki a wa Filasaiyepọ ri, nitori bi a ba le ri i, iwin ti iṣe alakoso fila rẹ̀ yio kó wa yọ. Nigbati a gunlẹ si odi keji tan, o wipe ki aburo on ti o jẹ iwin wa Filasaiyepọ wa ni ibikibi ti o ba ti le ri i. Were ti o wi bayi, ṣe ni aburo rẹ̀ rá mọ wa loju, nigbati o si fi mã to iṣẹju mẹta, ṣe ni mo ri i ti o nfo bọ̀ lofurufu ti o gbe Filasaiyepọ le ejika, ti o gbe e kalẹ lọdọ wa.

"Igbati iwin yi ri Filasaiyepọ nwọn yọ̀ mọ ara wọn, nwọn si ki ara wọn dãdã. Lẹhin nã o ni ki Filasaiyepọ pe iwin inu fila rẹ̀ fun on, onitọhun si ṣe bẽ. Nigbati iwin nã de, kò ga pupọ ṣugbọn o sanra o si ni ike nla kan lẹhin. On ati obinrin yi sọrọ si ara wọn ni èdè ti nko gbọ ri, lẹhin nã ni iwin ti iṣe alakoso fila yi bẹrẹ, ti o ni ki njoko le on lẹhin, nigbati mo si ṣe bẽ, were ni mo ba ara mi ni ofũrufu ti ó nfo lọ pẹlu mi. Aiya mi kọ ja ṣugbọn o sọ fun mi ki ndì mọ on lẹhin dãdã. Ki nmá ba ja lulẹ mo rọra dọbalẹ le e lẹhin mo di ike ẹhin rẹ̀ mu dãdã. Iwin nã ni irun lara bi ti ẹranko gãn ni, irun wọnyi ni mo si dì mọ pẹlu ike ẹhin rẹ̀ ti ko jẹki nja ṣubu. Nigbati o pẹ diẹ o gbe mi sọkalẹ si oju ọna Igbo Elegbeje, o si wi fun mi pe a ti kuro ni agbegbe ibiti Ẹlẹgbara mã nde, ṣugbọn o wi fun mi ki nmá kuro nibiti on gbe mi si nitori on nlọ mã gbe awọn yoku lọkọkan wa.

"Lõtọ nã, iwin inu fila yi bẹrẹsi wa awọn ẹnikeji mi yoku kiri, o ṣi ngbe wọn wa si ọdọ mi lọkõkan, bẽ l'o ṣe titi o fi gbe gbogbọ wa tan. Ṣugbọn nigbati a wo ãrin wa, a ko ri ọkunrin kan bayi ti o njẹ Ìgbín-enia, o jẹ ẹniti ki ifi ikanju ṣe nkankan rara, bi ó ba nrin pãpã nã bayi, tẹ̀nkìtẹ̀nkì l'o mã nrin kiri, igbati iwin nã gbe Ojuaiyedun de, nitori on l'o gbe kẹhin patapata, ó wi fun ni pe ko si ẹnikan lọhun mọ. A ba wi fun Olojumajele ki o ba ni fi ehin erin rẹ̀ wo inu igbo nã bọya o





lè jẹ ri i. Igbati o ṣe bẽ, kò ri i, ṣugbọn ó wi fun ni pe on ri Ẹlẹgbara pãpã, ó njẹ oku enia kan lọwọ ati pe oku enia nã jọ oku Igbin-enia, nigbati awa nã wo o, on ni. Ẹlẹgbara ti fa ọkunrin nã ya pẹrẹpẹrẹ, bayi ni a si nwo o ti o nfọn egungun agbari Igbin-enia bi ẹni nfọn fere.

"Ninu gbogbo wa, ko si ẹniti kò fi ara pa afi Ibẹmbẹ-olokunrun. O jẹ ẹniti o sanra pupọ o si ya mi lẹnu bi on ti ṣe lọ ni ori 're bẽ, igbati Ẹlẹgbara ti tú wa ka ti on si ti rọra fi ara pamọ sinu igbo ṣũru kan, Ẹlẹgbara ko ri i titi gbogbo wa fi nsa gun oke sa gun gegele.

"A duro, a simi diẹ, olukuluku rohin ohun ti on ba pade ni ibiti on ti nsa kiri, a dupẹ lọwọ iwin inu Filasaiyepọ ki ó to tun di pe ó pada wọ inu fila ọrẹ wa lọ. Lẹhin eyi, a kọju si ọna wa. A rin titi ilẹ ọjọ keji fi ṣu lai ri iyọnu kan afi ti Ibẹmbẹ-olokunrun ti o nkigbe ebi. Igbati ilẹ ọjọ kẹta mọ hai ni a ja si agbo awọn ẹran kan bayi ti nwọn ko si sa fun ni titi a fi kàn wọn lara. Nwọn tobi pupọ, ọkọkan wọn tobi to malũ dãdã, a pa ninu wọn, gbogbo wa jẹ, Ibẹmbẹ-olokunrun si pa pupọ jẹ ninu wọn.

## ILU AWỌN ÈDÌDÀRẸ̀ NI IBITI OMUGỌDIMEJI TI NṢE ỌBA WỌN

"Nigbati a kuro ni ibiti awọn ẹranko wọnyi wà ti a tubọ rin diẹ siwaju a ri ọna kekere kan bayi ti o yà ba apa osi lọ. Nwọn kọ àkọlé kan si ìyànà nã, nkan ti nwọn si kọ ni eyi: 'Ilu awọn Èdìdàrẹ̀ nibiti Omugọdimeji ti nṣe ọba wọn.'

"Akọle yi yà wa lẹnu a si yà si ọna nã ki a ba lọ wo bi ibẹ ti ri. Nigbati a rin si iwaju diẹ, a bẹrẹsi wo ilu nã ni ọkankan ṣugbọn ọna ti a ntọ̀ lọ tubọ ndi kekere si i afi bi ẹni pe enia ko ngbe ilu nã ni, nigbati o sa pẹ ṣa, a yọ si ilu yi.

"Emi ni mo wi fun yin, ẹnyin ọrẹ mi, lọjọ ti mo ti de inu aiye nko ri ilu ti o jẹ elẽri bi ilu yi ri. Igbati a de ãrin ọja, gbogbo ibẹ nrùn ni, ko dabi ẹni pe ẹnikẹni gba ãrin ọja nã ri. Gẹgẹ bi àṣà wọn, arugbo l'o nta ọja, on l'o gbọdọ kiri, gbogbo awọn ti a si ba ninu ọja nã ko ju adọta lọ, gbogbo wọn ni nwọn ti fi gbogbo ori hu ewu patapata, nwọn ìbá si tilẹ pọ̀ ju bẹ̃ lọ bi ko ṣe pe nwọn kò npẹ ku ni ilu nã. Ori ipanti ni nwọn gbe gbogbo ọja tità le. Ihõho ni pupọ ninu awọn ti a ri wà, ọdun mẹta mẹta ni nwọn to nwẹ̀, nitori eyi, ẽri ara wọn pọ tobẹ̃ ti o jẹ pe bi nwọn ba nkọja, ẽri ngbọ̀n silẹ ni. Mo ro pe eleyi nã l'o mu ki kúrúnà kuku pọ tobẹ̃ ni ilu nã, ṣugbọn eyiti o buru ju kuruna ni egbo ẹsẹ olukuluku ti o duro gẹgẹ bi àṣà fun awọn gbajumọ. Ewe kekere ko to lati fi bò wọn, omi egbo ẹsẹ awọn ara ilu nã a si mã kán silẹ bi nwọn ba ti nrin lọ. Ina ori ati ina aṣọ pẹlu ogunlọgọ ìdun ti ṣe ọ̀nà si ara wọn. Awọn kọkoro wọnni ri i pe ibẹ dara gẹgẹ bi ile fun awọn. Kò si ibiti jìgá kò le wọ̀ lara awọn Edidarẹ, jiga kọ pẹtẹsi si wọn ni atẹlẹsẹ, ó kọ ile ilẹ si wọn ni ibadi, ṣugbọn ori ni ãfin awọn ina wa. Ẽkan ọwọ wọn mú bi àdá, igbati nwọn ba si nhọ ara, a mã dun kùràkùrà bi igbati agbẹ ba nfi ọkọ ro oko. Omi ti nwọn nmu ni ilu yi buru gidigidi, nitori eti odò ti nwọn npọn ọ ni nwọn nṣe igbọnsẹ si bẹ̃ni odò nã ko ju kekere lọ.





"Nigbati a ti de ãrin ọja wọn ti a wo iwa wọn ti o buru bi mo ti rohin yi ni a ti pinnu pe o yẹ ki a pa agọ si eti ibẹ ki a wò wọn fun ọjọ melo kan. Agọ ti a pa to iṣẹju mẹ̃dogun si ilu yi, nitori eti ibẹ kò wù wa lati pa agọ si.

"Eyiti o buru pupọ ni ilu yi ni iwa wọn si ara wọn. Gẹgẹ bi àṣà awọn Èdìdàrẹ̀, ọmọde l'o ni aiye, awọn agbalagba ko jamọ nkankan. Bi ilẹ ba mọ, baba a dọbalẹ fun awọn ọmọ rẹ̀ kakiri ile, iya a tun kunlẹ̀ fun wọn. Bi ọmọde ba mã ranṣẹ, a ran agbalagba ni iṣẹ, bi ọmọde ati agba ba jẹun tan, àgbà ni nfọ awo. Awọn obinrin ni nṣiṣẹ lile afi ẹkọkan ni awọn ọkunrin nran wọn lọwọ ṣugbọn igbati awọn obinrin ba da oko tan nwọn a wa iṣu le ọkọ wọn lori, a ru u bọ̀ lati oko. Bi ọmọde ba ti gbe nkan ti ó wuwo diẹ lọwọ, awọn agba nilati sare gba a lọwọ rẹ̀. Bi ọmọde ati agba ba lọ si oko ibã ṣe ọkunrin ibã ṣe obinrin, àgbà ni o nilati ru ẹrù bọ̀. Igbati nwọn ba si wà ni oko, àgbà ni ó nilati da ina ki o se onjẹ.

"Nwọn ki isinku ni ilu nã. Bi ẹnikan ba ku, onjẹ de, nitori jijẹ ni nwọn njẹ oku ara wọn ṣugbọn nwọn kò jẹ dede pa ara wọn jẹ. Bi ọpọlọpọ ba ku pọ lẹ̃kanṣoṣo nwọn a rọra gbe oku wọn si àgbàlá nwọn a mã jẹ ẹ diẹdiẹ. Bi o si tilẹ jẹ pe nwọn mã nsun ẹran enia ki nwọn to jẹ ẹ, sibẹ, nwọn kò mọ ọna ati yan oku ti o ba ku ti kò ni fi bajẹ, igbati nwọn ba si gbe e si ẹhinkunle to bi ọjọ mẹta, eyini a bẹrẹsi rùn ṣugbọn akoko nã ni nwọn mã nsare pe ọrẹ wọn ki o wa jẹ ase ni ile wọn, nwọn a ni awọn nṣe sarã ki ẹmi awọn ba gbó.

"Bi nwọn ti nkọ ile wọn ko dara rara, nitori ki isi ẹyọ ferese kan ni ile wọn gbogbo ibẹ a ṣokunkun dudu, atẹgun ki isi iri aye de ibẹ ju bẹ̃ lọ. Koriko ni nwọn fi nbo ile wọn igbati ojo ba si rọ̀, igba pupọ ni ile njò ti gbogbo ilẹ a tutu nini, eweko ni nwọn ntẹ silẹ sun, nwọn a fi okuta ṣe irọri, nwọn ko ni ẹní kan ṣoṣo.

"Bi mo ti wi lẹ̃kan, aṣọ ko wọpọ ni ilu nã, ninu agbo ile ibẹ, pupọ l'o jẹ pe aṣọ kan ṣoṣo ni ó wà fun gbogbo wọn, nwọn a si ṣe eto bi awọn o ti ṣe lo o. Ẹnikọkan ni isaba mã lo o lojojumọ, eyini ni pe bi awọn ọmọ ile nã ba jẹ ọgbọ̀n, oṣõṣu ni aṣọ nã o to mã kan ẹnikọkan, nitorinã ni akoko otutu, ewe ni nwọn nlo jù bi aṣọ.

"Gẹgẹ bi ẹnyin nã ti le mọ, ilu ti o kun fun ẽri bi iru eyiti mo sọ yi ko le ṣai ni awọn alaisan ninu. Ko si ibi nã ti o wà ni ode aiye yi ti aisan pọ si ti o tayọ ti ilu Edidarẹ nibiti Omugọdimeji ti nṣe ọba wọn. Ki a tilẹ mu ti ẽri kuro, kini ki a ti pe ti ile wọn ti ko ni ferese tabi ilẹ ile ti o tutu nini, kil'o le mu aisan wa ti o kọja iru eyi!

"Bi itan ibẹ ti lọ, ilu nã ni o tobi ju ni ode aiye ni aiye atijọ, odidi ọjọ mẹta ni nwọn fi nrin lati apakan de apa keji ṣugbọn nkan ti o sọ wọn di bi nwọn ti wà yi ni irẹpọ ti ko si lãrin wọn. Nwọn jẹ ẹda ti o mọ ti ara rẹ nikan tobẹ̃ gẹ̃ ti ko si iru wọn ṣãju wọn ti ko si le si iru wọn lẹhin wọn. Nwọn kun fun owu jijẹ tobẹ̃ ti o jẹ pe baba ko jẹ fi nkankan han ọmọ rẹ ọkunrin, iya kò ni jẹ ki ọmọbinrin rẹ tilẹ wo bi on ti nse ọbẹ̀. Nipa ṣiṣe bẹ̃, ohun ti ẹnikan ba mọ ẹni keji ko ni imọ ọ, bẹ̃ bẹ̃ ọgbọn wọn nparẹ.

"O pẹ diẹ ti a ti de ilu nã ki a to mọ ọba wọn. Ohun ti ko tilẹ kọ jẹki a lọ si ile ọba wọn kò ju eyi pe niwọnigbati ilu nã ti buru to bi a ti ba a yi a ko ni ero giga kan nipa ọba ibẹ rara, nitori ko si ọba pataki kan ti o le fi oju ara rẹ silẹ titi ilu fi mã buru to bi a ti ba a nì.

"Ohun ti o mu ki a tilẹ pinnu ati lọ mọ ile ọba nã ko ju ti Ilẹ̀'—'gbona ti o bẹrẹsi ja ti o si jẹ pe o npa pupọ ninu wọn.

"Nitori eyi, a ranṣẹ lọ sọ fun ọba pe a nbọ wa ri i nipa ọrọ kan ati pe ki o sọ igbati on le ri aye ri wa. Nigbati onişẹ pada de, o wi fun wa pe ọba ni ki a wa si ãfin ni owurọ ọjọ keji ni agogo mẹjọ-abọ.

"Nigbati ilẹ ọjọ keji mọ ti a jẹun a lọ si ile ọba. A de ọhun ni agogo mẹjọ kọja iṣẹju mẽdọgbọn, igbati o si to agogo mẹjọ-abọ gãn, a ri ẹnikan ti o nbọ lati ãfin a si wi fun u pe ọba wi fun wa ki a wa ri on, ẹni nã ba pada wọ ãfin lọ lati lọ sọ fun ọba, ṣugbọn nigbati o mã pada de, o wi fun wa pe, ọba Omugọdimeji ti lọ si oko.

"A duro diẹ bọya ko ni pẹ ti oko de, ṣugbọn nigbati o ṣe a pada lọ si àgọ wa.

"Ni alẹ ọjọ nã, ni nkan bi agogo meje, a tun ranṣẹ lọ si ãfin lati ba wo bi ọba ba ti de, nigbati onişẹ wa pada o wi fun wa wipe ọba ko iti ide.





"Bi ilẹ ti nmọ ni ọjọ keji, ti a ri i pe o to akoko ki ọba ti mã ri awọn enia rẹ, a tun ranṣẹ lọ si ãfin. Igbati onişẹ pada o ni ọba wipe o rẹ on lọjọ nã pupọ nitori ẹrù ti on rù bọ lati oko lọjọ ti a kọ wa a lọ pọ ju eyiti on ti nrù bọ̀ ri lọ, ati pe ki on to tun le ri wa di ọjọ keji eyini ni nkan agogo mẹsan, eyini ni ọjọ kẹta ti a ti nwa a lọ si ãfin.

"Ni agogo mẹsan gẽre ni a de ãfin ni ọjọ ti o tun da yi, a tilẹ kọ ṣebi a pẹ ni, ṣugbọn nigbati a de ọhun ni a mọ pe a de si akoko gãn. Bi a ti de ọhun ni a tun ran onişẹ kan wọ ãfin lọ. O pẹ diẹ ki onişẹ nã to pada, ihin ti o si wa mu ba wa ni pe ọba ko si ni ile, ati pe o lọ si oko, nitori iṣu ti o mu ti okọ bọ ni ọjọ ti a kọ fi wa ko to fun onjẹ awọn ti ngbe ãfin. A tun duro diẹ bọya a le ri i, ṣugbọn, irọ ni. Lẹhin eyi a pada lọ si ibudo wa, a si ranṣẹ si ilẹ de e wipe a ti wa si ãfin.

"Nigbati o di alẹ ọjọ yi mo tun ran ẹnikan lọ si ãfin lọ wo ọba bọya o ti de. Igbati onişẹ si mã pada, o wi fun ni pe ọba ti de ati pe o nfẹ ri wa ni ọjọ keji ni agogo mẹsan-abọ. A de ọhun bi o ti wi lọjọ keji lõtọ, ṣugbọn ọba ti lọ si oko.

"Bayi ni Omugọdimeji bẹrẹsi ṣe titi o fi di alẹ ọjọ kẹfa ti o ranṣẹ pe ki a ri on ni nkan bi agogo mejilã ọsan ọjọ keje. Nigbati o di ọjọ keje yi, a de ọhun ni agogo mẹwa dipo agogo mejilã ti ó da, ọjọ nã l'a si kọ ri i.

"Mo fẹ ki ẹ mọ pe lati ọjọ ti a ti nranṣẹ yi, onişẹ wa pãpã ki ifi oju ri ọba nã, ṣe ni nwọn mã njiṣẹ fun u ti ẹniti a ba ran nã mã nranṣẹ wọ ãfin lọ bi a si ṣe ri ọba yio yà yin lẹnu.

"Ãfin ọba Omugọdimeji ko dara to abà oko rara, ogiri ti nwọn si mọ yi i ka, ẹsẹ meji ni giga rẹ.

"Lowurọ ọjọ keje ti mo nsọrọ rẹ yi, nigbati a de ãfin, a ri ẹnikan ti o joko le ori ogiri ti o yi ãfin po. O san ibàntẹ́ mọ idi o si pọn ibantẹ nã ni ìkólóbo. O tun de fila gbõrọ kan bayi, kò wọ ṣokoto, ko wọ ẹwu bẽni ko si wọ bata rara. Ọkunrin yi ni a ba ni ori ogiri. Inu wa dun ti a ri i nitori a nfẹ ki a tete ri ẹniti yio ba wa wọle lọ sọ fun ọba pe a ti de. Gbogbo igbati a ti mã nwa sẹhin wọnni ni iya mã njẹ wa ki a to le ri ẹni ran wọle, nitori eyi inu wa dun ti a tete ri ẹnikan ni ọjọ ti a nwi yi.

"Were ti a ti ri ọkunrin yi l'a ti sọ fun u pe a fẹ ki o ba ni

wọle lọ sọ fun ọba pe a ti de. Nigbati a wi bayi, ọkunrin nã bẽre nkan ti a fẹ ri ọba fun, a si wi fun u pe a ko iti iṣetan lati sọ eleyini fun ẹnikẹni ati wipe o di igbati a ba ri ọba ki a to sọ ọ fun u. Igbati o si ntẹnumọ ọ pe ki a sọ fun on, inu bi wa, a ṣebi o nfẹ gba abẹtẹlẹ lọwọ wa ki o to wọle lọ sọ ni.

"Ibiti a ti jọ nsọrọ si ara wa yi ni ọkunrin kan ti de, nigbati o si de iwaju ẹniti a nba sọrọ yi, o dọbalẹ o si ki i 'Kabiyesi, alaṣẹ, ekeji oriṣa!' Irũ kiki yi jọ wa loju a si bẹrẹsi ro ninu ara wa pe bọya bẽ ni nwọn ṣe mã nki iranṣẹ ọba ni ilu nã. Ṣugbọn ibiti a ti nronu bẽ ni ọkunrin ti a nba sọrọ wi fun eyiti o ṣẹṣẹ de pe awa ti a nlọ si idalẹ ni o ri niwaju on ati pe a ko tilẹ mọ on pãpã. Akoko nã ni ẹniti o ṣẹ̀ṣẹ̀ de yi sọ fun wa pe ọba ni a nba sọrọ ati pe on ni ẹniti nje Omugọdimeji ti iṣe ọba ilu awọn Èdìdàrẹ́. Bi ọkunrin nã ti sọ bayi tan ni a tọrọ aforiji lọwọ ọba pe a kò mọ̀ pe on ni. Lẹhin eyi ni Omugọdimeji bẹrẹsi ọrọ isọ ti o ni,

"'Ẹnyin alaimoye, ẹnyin alaigbọ̀n, jijoko ti mo joko, nkọ̀ joko ni ijoko ọba ni, tabi aṣọ ti mo wọ̀ ni ko to ti ọba? Bi ẹ ko mọ nkan ẹ ko mọ iyi ibantẹ mi? Bi oju yin tilẹ fọ ẹ o sọ pe ẹ ko ri ade mi ni? Bi ẹ ko tilẹ mọ gbogbo rẹ̀, ẹ ko ri ãfin mi ti o lokiki jakejado aiye? Ọba wo l'o to mi? Enia wo l'o gbọn bi emi? Tani ọba nã ni ode aiye yi ti o le fi ọwọ sọ aiya pe ilu on dara bi ilu mi? Ẹnyin ti ẹ l'oju ti ẹ ko le fi riran—Bi ẹ ko ba ṣọra yin ng o ba yin ja ki ẹ to kuro ni ilu mi.'

"Bayi ni ọba nã sọ, ẹru si ba gbogbo wa pe bi ilu rẹ̀ ti bajẹ to nì, ó dara l'oju ọba! Ọjọ nã ni mo si to wa mọ pe ọmugọ ti o ta gbogbo omugọ yọ ni ki ẹniti o gọ̀ rò pe on gbọn, nitori igbati enia kò ba gbọn ṣugbọn ti ko mọ pe on ko gbọn, ati gba ọgbọn ẹlomiran ko ni ṣai jẹ iṣoro.

"Nigbati ọba pari ọrọ rẹ̀ ti mo nfẹ sọrọ ni Aiyederu-ẹda dide o ni on nfẹ sọrọ fun u, nigbati o si mã sọrọ o ni: 'Kabiyesi inu mi dun lati mọ yin loni. Ẹ maṣe binu pe a ko mọ yin nigbati a de, ki iṣe gbogbo wa ni ko mọ yin, nitori emi ti mo duro yi, riri ti mo ti ri yin ni mo ti mọ pe ọba pataki ni ẹ jẹ. Ilu yin le ṣai dara loju ẹlomiran, ṣugbọn emi ni temi, mo gbadun ilu yin nko si si ninu awọn ẹlomiran ti nsọrọ yin lẹhin pe ilu yi ko dara. Ọrẹ yin ni mo fẹ ṣe. Mo ki yin mo tun yin ki,





ku inawo ãfin yi, ẹ ku itọju ilu yi, ilu yi jọ mi loju, ẹ maṣe binu si mi ati awọn ọrẹ mi o, Kabiyesi.'

"Bayi ni ọkan ninu wa sọrọ, Aiyederu-ẹda ti o ṣe mi ni alejo ni ilu rẹ̀ ni ijọsi ti mo si fi ṣe igba keji mi ni irinajo si Igbo Elegbeje yi.

"Ki Aiyederu-ẹda to pari ọrọ rẹ̀ tan ni pupọ ninu wa ti a ti joko le ori ogiri kekere ti o yi ile Omugọdimeji po ti nfẹ sọrọ. Igbati o si pari ọrọ rẹ̀ tan, Filasaiyepọ dide, Olojumajele dide, Kumọdiran dide, gbogbo wọn dide pọ lẹ̃kanṣoṣo. Emi pãpã nfẹ sọrọ ṣugbọn nigbati mo ti ri awọn ẹnikeji mi gbogbo ti nwọn dide, emi joko mo si wi fun Filasaiyepọ ati Olojumajele ki nwọn joko ki nwọn jẹki Kumọdiran sọrọ, nitori on l'o kọ ṣãju gbogbo wa dide.

"Nigbati Kumọdiran bẹrẹsi sọrọ, aiya mi ja, o sọrọ yánnayànna o ni:

"'Omugọdimeji, inu mi ko dun lati mọ-ọ rara. Didun bawo? Iwọ, Omugọdimeji, ẹniti o pe ọ ni Omugọdimeji ko pe ọ bi o ti yẹ ki o pe ọ. Nitori kini nkọ, nitori Omugọ rẹ rekọja meji, omugọ rẹ ju meji lọ. Bi omugọ rẹ kò ba rekọja meji, ilu rẹ a bajẹ to bayi loju ara rẹ, iwọ a tun mã ri ẹnu sọrọ! Iwọ alakọri yi, ti o ṣe ikùn bi apo ekurọ. Ibantẹ wo l'o fi nṣe fari?—Ibantẹ ni ọba nsan? Fila rẹ gbọ̃rọ, bi oju rẹ kò ba fọ, fila rẹ ti iwọ npe ni ade yi dara ju fila ori awa lọ? Oni yi l'o di odidi ọjọ meje ti a ti nranṣẹ si ọ pe ki o jẹki a wa ri ọ, gbogbo adehun ti o nba wa ṣe ni o nyẹ̀, sibẹ o ko ronu ara rẹ wò. Emi ni mo wi fun ọ, Omugọdimeji, bi eti rẹ kò ba di, gbọ nkan ti a mã ba ọ sọ loni: ilu rẹ yi bajẹ tobẽ ti nko ri iru rẹ̀ ri. Aiye ti kuro ni ibiti ẹnyin wà yi, o nilati lọ mura ki o tun ero ara rẹ pa. Ọrọ pataki ni a wa lati ba ọ sọ loni, bi o fẹ bi o kọ̀ o nilati gbọ ọrọ nã bi o ko ba si fẹ gbọ ni oju bọ̀rọ̀, a o wi fun ọ ni oju lile. Ọrọ temi ko ju bayi lọ.'

"Bayi ni Kumọdiran pari ọrọ rẹ̀, nigbati o si sọ ọ tan mo ṣakiyesi pe inu awọn enia wa dun ṣugbọn ẹru ti nbà mi bi o ti nsọrọ nã bọ ki ija má ba bẹ silẹ nigbati ó ba pari ọrọ rẹ̀, nitori ọrọ ti ó sọ le, ṣugbọn iyalẹnu l'o jẹ fun mi pe nigbati Kumọdiran pari ọrọ rẹ̀, ẹrin ni ọba Omugọdimeji bu si, o rẹrin titi o fi yi lulẹ lori ogiri kekere ti o joko le nigbati o si dakẹ

ẹrin nã ṣe l'o kọju si ọkunrin ti o de ba wa nibẹ ti ó wi fun u pe ki ó mu wa lọ si ãfin ki a lọ joko de on, on nbọ.

"Bi nwọn ti ṣe eto ile Omugọdimeji yatọ pupọ si ti ile awọn ọba ti mo mọ. Ṣe, ni ãfin ilẹ Yoruba, inu ãfin patapata lọhun ni ile awọn ayaba nwà, kò ri bẹ̃ fun Omugọdimeji, ile awọn obinrin rẹ̀ l'o kangun si ibiti enia ngbà wọle, nigbati nwọn si mu wa wọ ile, ile awọn obinrin ni nwọn mu wa lọ. Gbogbo awọn obinrin nã wà ni ihõho, nwọn nwọle, nwọn njade.

"Mo ri ọgbọn diẹ kọ ni ibiti a joko si yi nitori ko pẹ ti a de ti awọn mẹta kan fi de wa ba ni, mo si fẹtisi ohun ti nwọn nsọ nipa ọba wọn. Omugọdimeji ko nãni ẹlomiran afi awọn ijoye rẹ̀ nikàn lãrin ilu, titi kan awọn olowo ati awọn ẹlomiran gbogbo ti ẹnu wọn to ilẹ lãrin ilu, kò fi tiwọn ṣe nigbati nwọn ko ti si ni igbimọ ki nwọn mã ti i lẹhin ninu ẹjọ ti ó ba nda. Nitori eyi, aṣĩri ọkunrin nã ko le bo, awọn ẹlomiran mbẹ lãrin ilu ti nwọn ju ijoye lọ, yala ni ipa ọgbọn, yala ni ipa ìmọ̀, yala ni ipa owo, yala ni ipa ãṣiki. Bẹ̃ni o yẹ ki ẹniti ó ba jẹ olori ilu mã fa gbogbo aiye mọra.

"Nigbati ó pẹ diẹ ti a ti de ãfin ni ọba ranṣẹ si iyawo rẹ̀ àgbà ki o fi ile on han wa. Obinrin nã sanra bayi, ó wà ni ihõho gidigbi. O mu wa yi ile nã po, ṣugbọn eyiti o yà mi lẹnu ju nibiti o ti nmu wa ka ni pe igbati a ba wọ iyãra kan, ko si nkan ti ó kù ninu ibẹ ti kò ni fi han ni. Bi o ba ri owo ninu apoti a ka gbogbo rẹ̀ fun ni, bi ó ba ri õgun ti nwọn fi nṣọra ninu ile a fi han ni, igbati o mu wa de ibiti nwọn ti nṣe igbọnsẹ o tun nfẹ lọ fi igbọnsẹ gãn han ni, a ba kọ fun u. O sọ aṣĩri ọba han wa, owo ti ọba ya lọwọ ẹlomiran ati lọwọ ẹniti o ti ya a, o darukọ awọn ti ọba gbà gẹgẹ bi ọta ati awọn ti ó gbà gẹgẹ bi ọrẹ o si sọ gbogbo ero ọba nipa awọn ijoye rẹ̀ lai ku ẹyọ kan ninu wọn. O fi ile onjẹ han wa, o ṣi ikoko ọbẹ̀, o ka iye ekiri ẹran ti o kù ninu gbogbo iṣãsun ọbẹ̀ fun ni. O darukọ gbogbo iyawo ọba han wa, o sọ bi ile iya ati baba olukuluku ti ri ati bi ọba ti fẹrãn olukuluku to, nigbati o si ntu aṣĩri ọkọ rẹ̀ bawọnyi mo wi fun u ki o ye sọ gbogbo nkan wọnni fun wa ṣugbọn o wi fun mi pe bẹ̃ ni bãle on ni ki on mã ṣe.

"Nigbati a yi ile nã po tan ti a pada de ibiti a ti kọ joko, a ri i pe ọba ko iti iwọle. Igbati o si pẹ ti a ti joko ni obinrin





kan pe ọkan ninu awọn iranṣẹ ile nã pe ki o pe ọba wa wipe iṣu ti on se ti jina ki ọba wa gun iyan ni ẹhinkunle.

"Nigbati o tun ṣe ni a ko gbọ ọwọ odo mọ, ko si ju iṣẹju kan ti ọwọ odo yi dakẹ ti ariwo ta ni ẹ̀hìnkùnlé pe ọba nja ti a bẹrẹsi gbọ gìrìgìrì ẹsẹ. Were a sare lọ si ibẹ, nigbati a si mã de ọhun iyawo ọba ti gbe ọba lulẹ, ori rẹ̀ ni a si ba a ti ó ngba ọba leti leralera, a ba mu wọn ti a gba ọba lọwọ rẹ̀.

"Igbati ọba tun dide tan, o ni afi bi on tun jà si i ati pe bi ko ba ṣe pe a tete mu awọn ni, on iba yi obinrin nã kuro lori on, eleyi nã ni a si nsọ ti ó já ọwọ rẹ̀ gbà lọwọ wa ti o tun pa gũru si obinrin nã, ki a to tun ṣẹ oju pẹ, ipakọ ọba ni a tun nwò ni ilẹ, awọn ara ile ọba tun mu wọn. Igbati o si jẹ pe ọba ko dakẹ, ija tun bẹrẹ lẹ̃kẹta, obinrin yĩ tun yi ọba mọlẹ. Ki nmá sa ba ọrọ yi lọ bi ilẹ bi ẹni, ẹ̃meje ni obinrin yi gbe Omugọdimeji lulẹ loju wa, igbati nwọn si jàjà gba ọba silẹ lẹ̃keje yi ṣe l'o gbe ire dà silẹ ti obinrin yi nã gbá tẹle e, o le e pẹ titi ki ó to pada lẹhin rẹ̀.

"Nigbati obinrin yi pada tan, gbogbo wa tọ ọba lọ si ibiti o duro si, a si bẹrẹsi ba a gbọn ipanti ori rẹ̀, awọn ipanti ti ó dì mọ ọ lori gbogbo ni ibiti obinrin nã ti ngbe e yilẹ. Ọba pãpã fi ọwọ gbọn erupẹ ti ó lẹ̀ mọ ọ ni idi ti o mu ki idi rẹ̀ dì pupa. Ibiti a ti nṣe eyi ti a nki ọba ni ọkan ninu awọn ijoye rẹ̀ ti dahun ti o ni, 'Kabiyesi, kò nà yin to ti ijọsi loni'. Ọba nã si fesi o ni, 'Bẹ̃ni, mo ṣẹ̀ṣẹ̀ nmọ ọwọ obinrin nã ni, nitori mo gbe e lẹ̃kan bi ẹni ki nlà a mọlẹ afi ipanti ti ó kọ́ mi l'ẹsẹ l'o jẹki ó bọ lọwọ mi'. Ẹnikan tun bẽre o ni, 'Ṣe kò ta yin ni ipa loni?' On nã si tun dahun o ni, 'O ta mi ni ipa diẹ, ṣugbọn ẹsẹ rẹ̀ kò ba mi ni ibi buruku'. Ọkan tun ṣe ibẽre o ni, 'Ade yin dà?' Ọba tun dahun o ni, 'Ibiti o ti nnà mi ni ade mi ti ṣi bọ sinu odo, nko tilẹ mọ ibiti ó wà bayi'. Lẹhin eyi ni Kumọdiran ṣe ibẽre ti o ni, 'Bawo ni ija nã tilẹ ṣe bẹrẹ?' On nã si wa sọ o ni, 'Bi mo ti ngun iyan ni obinrin nã bẹrẹsi bu mi ti o wipe ọwọ mi kò ran odo iyan, emi ngun iyan tipẹtipẹ, ati pe ẹnu ni emi le mã fọn kiri, ko si nkankan ti mo le ṣe ni mo ba ni ki ó yé bu mi, nko wi ju bẹ̃ lọ, afi "gbàì" ti mo gbọ leti mi ti ó gba mi leti, ni mo ba bẹrẹ njẹ ki nko o l'ẹsẹ ki nna a mọlẹ ni ogedengbe, bi mo ti bẹrẹ bayi, ṣe l'o gbe mi ni ipa

ti mo fi ori na ọlọ ata. Ọrọ kekere l'ẹ pe e, diẹ l'o kù ki obinrin nã fọ mi lori, ṣe l'ori nta mi fõ bi mo ti nsọrọ yi, ṣugbọn ko yà mi lẹnu, bẽ ni iya rẹ̀ fọ baba rẹ̀ lori ti nwọn fi si ẹwọ̀n, idile fọrifọri ni idile wọn'. Emi nã wa dahun mo ni 'Igbati ẹ mọ pe idile buruku bẽ ni idile wọn kini ṣe ti ẹ fi fẹ ẹ?' O fesi o ni, 'O ko ri i pe ó l'ẹwa ni? Jẹki nwi fun ọ, on pãpã ti wọ ẹwọn lẽmẹta, ọjọ kẹta ti o jade l'ẹwọn ẽkẹta ni mo fẹ ẹ, o wù mi gãn ni'. Ibiti a ti nsọ eyi ni ẹnikan ti ti ode wọlẹ ti o ni on nba ọba kẹdun o ni, 'Kabiyesi ẹ ko lọ tubọ mura? Ẹ ko lọ mura?—Ki obinrin mã na oluwarẹ̀ lojojumọ bayi! Oju mà ntì awa o.' Igbati ọba gbọ bẽ o dahun pẹlu ibinu o ni, 'Bi oju ba lè tì yin ki o mã tì yin, bi ẹ ko ba ri i bi o ti ga soke fiofio ni'. Igbati Filasaiyepọ si wi bayi pe, 'Igbati ẹ mọ pe ipa yin kò ni ka a kini ẹ fẹ ẹ si?' Ọba tun binu, o ni, 'Mo ti sọ fun alakọri yin lẽkan pe ó wù mi ni'. Lẹhin eyi, Aiyedèru-ẹda sọrọ o ni, 'Mo mọ daju ṣa pe bi obinrin nã ba tun de ẹ o ba a fi ija pa ẽta'. Omugọdimeji nã wa rọra rẹrin diẹ bayi o ni, 'Dajudaju, bi o ba tun le yọ si mi ng o lu u, ng o fẹrẹ pa a, nitori mo ti mọ ọwọ rẹ̀ nisisiyi, nko jẹ bẽ rara, nko jẹ bẽ rara bi ẹ ti nwo mi yi o, ẹ maṣe f'oju di mi o, tabi ẹ ro pe ọkọ yẹpẹrẹ kan lasan ni mi ni?—O mà tì o, ki iṣe bẽ rara, tabi ẹ kò ri i bi mo ti npọn ìkólòbo dan? etc., etc.'

"Ẹnyin ọrẹ mi, ọba nã ko iti isọ ju bayi lọ afi igbati ẹnikan dede kigbe, 'O de, O de, obinrin nã tun de o!—' Kini ọba gbọ bẽ ṣe! Omugọdimeji gbe ire dà silẹ, iyawo fi tẹle e, ọran di 'B'õ lọ yà fùn mi, nigbati gbogbo wa si nwo ipakọ ọba bayi, ẹrin l'a bú si, a rẹrin titi àríntàkìtì ni—bẽni ipakọ Omugọdimeji ṣe bi ẹni gùn diẹ bayi, ó si tun wa tẹ̀ diẹ, ó ri kọnkọ. Ibiti o ti nsalọ, ìbantẹ tu, o wa fi ọwọ mu ibantẹ mọ idi, okun eleyini nfì dirodiro.

"Nigbati o pẹ ti obinrin nã pada lẹhin ọba, a lọ ba a nibiti o sa pamọ si nigbati a si nba a sọrọ ó ju ọwọ si wa o ni ki a rọra mã sọrọ ki ẹniti o nle on má ba gbọ. A wi fun u pe a nfẹ lọ si ibudo wa ati pe a ko ro pe a le sọrọ ti a ba wa mọ lakoko nã. On nã gbà bẽ fun wa, o ni ki a pada wa ni oju alẹ. Bayi ni a fi ãfin ọba awọn Edidarẹ silẹ ti a wa si ibudo wa.

"Nigbati o di oju alẹ, a wa si ãfin, igbati a si mã de ọhun,





ija nã ti rọlẹ, ọkan ọba pãpã ti balẹ, o si fetisi gbogbo ọrọ ti a ba a sọ. Ṣugbọn ọba nã jẹ ọkan ninu awọn ẹda wọnni ti nwọn mã njẹ ọlọgbọn loju ara wọn, ti nwọn mã njiyan de gongo lori nkan ti kò yẹ ki enia jiyan le, nwọn ki ifetisilẹ ki nwọn gbọ imọran ẹnikeji, nwọn a mã le koko le ori ohun ti kò yẹ. Nigbati a wi fun Omugọdimeji pe Ilẹ̃-'gbona kò dara, o ni o dara ni ti on, ati pe on ni nmu ara enia le, ati pẹlu pe bi Ilẹ-'gbona ko ba ti imu enia oluwarẹ̀ ko iti ibọ sinu aiye. Igbati a ni ko yẹ ki gbogbo enia mã fi ara mọ ẹniti Ilẹ-'gbona ba nṣe bi a ti nri wọn ti nwọn nṣe wọnni, o ni on gãn l'o yẹ, igbati a wipe ẽri ilu nã pọ ju ati pe bi nwọn ti ṣe nkọ ile wọn ni o nmu aisan de ba wọn, o ni, irọ ni a npa.

"O ya mi lẹnu pupọ pe nigbati ogunlọgọ lode aiye ko iti imọ nipa pe ki a mã bu apa fun ni ki Ilẹ—'gbona má ba ṣe ni, ni awọn Èdìdàrẹ̀ ti mọ. Bi itan nã ti lọ ni yi. Ni aiye atijọ, ọkan ninu awọn iranṣẹ Olodumare a mã yi aiye po lọdọ̃dun orukọ rẹ̀ a mã jẹ Imọlẹ. A mã yi aiye po lati ba wo bi awọn araiye ba ti nṣe. Igbati o ba nlọ, a mã yi ara pada si bi o ba ti fẹ ni, igbamiran a wa bi ọmọ kekere, igbamiran a wa bi agbalagba. Ni ọdun kan, nigbati ó wa, o sọ ara rẹ̀ di arugbo kùjọ̀ù, o si gbe ẹru leri, o duro si ẹba ilu awọn Edidarẹ, nigbati ọmọ ọba nlọ si oko ti o ri i, nwọn ki ara wọn, arugbo yi si wi fun u ki o ba on gbe ẹru on diẹ. Ọmọ ọba yi kó ja a ni iyàn rara, o ba a gbe e—nwọn jọ nlọ. Nigbati o ṣe, nwọn de ibi odò kikun kan, ọmọ ọba gbe ẹru kọja si odi keji, ṣugbọn arugbo yi duro, o ni on ko le kọja si odi keji, afi bi ọmọ ọba nã ba tun gbe on, ọmọ ọba ṣe bẽ. Igbati nwọn wa de odi keji na wayi o, ni iranṣẹ Olodumare yi ara pada ti o funfun báláú ti o ga soke fiofio, o dahun o si wipe, 'Nitori iwọ ṣe mi lõre yi, lati oni lọ ng o mã ranṣẹ wa lati ode ọrun ni ọdọ̃dun ki awọn iranṣẹ mi mã sin yin ni gbẹrẹ, ki Ilẹ—'gbona má ba ba yin jà mọ, yio si ṣe, ẹniti o ba fi ara rẹ̀ silẹ fun gbẹrẹ sisin yi, kì yio ri ija Ṣọpọnna bi gbogbo enia tilẹ nku bẹrẹ.'

"Bayi ni itan apa ti nwọn nbù ṣe lọ.

"A gba ọba nã ni iyanju pe ki o jẹki nwọn bu apa fun on ṣugbọn gbangba l'o wi fun wa pe on ko ni ijẹ, a ba kuro ni ãfin.

"Nigbati o to ọjọ mẹfa lẹhin eyi ti mo tun lọ si ãfin njẹ ki

nlọ bẹ ọba wo, biba ti mo ba a bà mi lẹru lọpọlọpọ, Ilẹ—'gbona ti bo o, ṣe l'o ngbin ni ẹ̃kọkan, igbati mo ki i, kò le da mi lohun mọ ãnu rẹ̀ si ṣe mi. Ko ju ọjọ meje lẹhin eyi ti a gbọ pe ọba nã ku."



## OMUGỌDIMẸTA G'ORI OYE, SỌPỌNNA GBE OMUGỌDIMEJI LỌ

Ibiti alejo mi sọrọ nã fun mi mọ lọjọ ti a tun nkọwe nã ni eyi, a ba da ọwọ duro lọjọ nã, a ki awọn ti o wa gbọ ọrọ wa pe ki nwọn mã lọ sile ki nwọn tun pada lọjọ keji.

Ko pẹ pupọ ti ilẹ ọjọ keji si mọ ti gbògbo enia tun fi nrọ wọ ile mi, igbati awa nã si jẹun tan, alejo mi tun bẹrẹ o nba itan nã lọ o ni:

"Ẹnyin ọrẹ mi, ibiti mo ba irohin nã de lana ni iku Omugọdimeji.

"Bi awọn Edidarẹ ti ṣe lẹhin iku rẹ̀ yà mi lẹnu. Igbati mo lọ si àfin, ṣe ni mo ba gbogbo wọn ti nwọn nyọ, igbati mo si bẽre idi ayọ yi lọwọ ẹnikan bayi o ni, 'Gbogbo wa nyọ nitori ẹran de, idi Omugọdimeji ri bẹ̀mbẹ̀ bẹmbẹ, ikùn rẹ yọ bọ̀mbọ̀ bọmbọ, on pãpã tobi o ri yọ̀kọ̀tọ̀ yọkọtọ, ẹran ibadi rẹ̀ ko ni ṣai ṣe ọ̀rá ṣinkìn si wa lẹnu. Ko si ẹniti o wà ninu awọn Edidarẹ ti ó fẹ ki on pãpã ku, ṣugbọn olukuluku ní inu didun si iku ọmọnikeji rẹ̀. Ilu buruku gbã ni.

"Ni ọjọ keje ti Omugọdimeji ku ni nwọn fi akọbi ọmọ rẹ̀ joye, orukọ ẹniti njẹ Omugọdimeta. Ni ọjọ kẹta ti Omugọdimẹta joye ni awa nã mura ti a lọ ki i gẹgẹ bi alejo ni agbegbe ibẹ. Ọjọ nã ni mo kọ mọ iya rẹ̀ ẹniti orukọ rẹ̀ njẹ Ìlábùrù. Nwọn ṣe wa ni alejo gẹgẹ bi nwọn ti gbọn mọ, nitori awẹ obi kan ni Ilaburu fi fun gbogbo wa. Nigbati a ki i tan, a lọ ki aburo Omugọdimẹta orukọ ẹniti njẹ Danasungbo. Ọdun kan-abọ pere ni Omugọdimẹta fi ju Danasungbo lọ, ṣugbọn ikini ti o ki ni, ko jọ ikini aburo ọba, dipo ki awa dọbalẹ fun u, on l'o tun dobalẹ fun wa, ko si dọbalẹ lẹ̃kanṣọṣọ gbogbo wa l'o ki lọtọ ọtọ ti o dọbalẹ fun olukuluku karikari.

"Ni akoko ti Omugọdimẹta fi nṣe ti oye yi mo bẹ ãfin wo to igba mẹta, nitori ko si igbati mo nde ọhun ti iya rẹ̀, Ilaburu ko nki mi dãdã. Bi o ti wu ti obinrin ṣe alaigbọn to, ko ni ṣai

fẹran ọmọ rẹ, bẽni bi a ba fẹran ọmọ ẹni, ọrẹ ọmọ nã, ọrẹ ni yio jẹ fun ni.

"Nigbati o pẹ ti ọba tuntun yi ti jẹ, o bẹrẹsi lọ si Igbimọ, igbati ó si di ọjọ kan ti mo lọ ki i, o wi fun mi pe on nfẹ ki nwa wo bi nwọn ti nṣe Igbimọ ni ilu on. O wi fun mi pẹlu pe ẹṣin ni a o jọ gun lọ si Igbimọ nã lati ile on, nitori on ṣẹṣẹ ra ẹṣin meji nã on yio si kọ gun ọkan lọjọ ti a ba mã lọ ki emi nã gun ekeji. A da ọjọ lilọ.

"Nigbati ọjọ lilọ pe mo lọ si ãfin. Iyalẹnu l'o jẹ fun mi lati ri i pe nigbati ẹniti ọba ran ki o lọ mu ẹṣin wa mã yọ, malũ l'ó mu wa. Nigbati mo ri i, mo wi fun ọba mo ni, Ha ! Ọba Edidarẹ, malũ ni ẹ npe ni ẹṣin ! Oju ko si ti ọba nigbati mo wi bẹ, o dahun o ni, ohun ti awọn npe ni ẹṣin ni ilu awọn ni eyini. Were ọba tọ le ọkan ninu awọn malũ wọnni, igbati malũ ju ori, ẹhin ọba, ilẹ l'o lọ, malũ tilẹ nfẹ lọ fi iwo gun u mọlẹ ki nto na malũ ni igi. Eyi kọ emi ni ọgbọn, nitorinã nko gun malũ temi, igbati ọba si rá pálá dide tan ó tun tọ le malũ lẹhin o nlọ pẹlu hilahilo.

"Nigbati a de Igbimọ ni ọjọ nã, a ba awọn enia ọpọlọpọ ti nwọn nsọrọ ti nwọn nsa kakiri inu ile nã. Igbati emi ati ọba si wọle, nwọn ko dakẹ rara, ẹnikẹni kò tilẹ sọ pe on ri wa, ṣugbọn nigbati ọba kigbe soke, ti ó dide duro, ti ó ni ki awọn ka igbagbọ nipa onjẹ, ṣe ni gbogbo wọn dakẹ minimini. Oku onjẹ ni wọn, emi pãpã ko gbọ Igbagbọ Onjẹ ri, ọjọ nã ni mo kọ gbọ ọ, ng o mã ka a nisisiyi, ki ẹnyin nã mã ka a tẹle mi :

"'Mo gba onjẹ gbọ, on ni alakoso ara, onjẹ didara, a mã mu ara dan, a mã mu egungun le, ẹ̀jẹ̀ a ṣàn kakoko, aidara onjẹ, ni nfa aisan lẹsẹ, ijẹkujẹ onjẹ, o nsọ ara di arugbo, ẹrẹkẹ a di palaba, oju a di foforo, imu a di tọgila, ẹsẹ a di tĩnrin, apa a di jawala, iwaju a di gọmbu, idi a di pẹlẹbẹ, gbogbo àwọ̀ ara a ri kùọ̀kuọ. Mo si gbagbọ pẹlu pe, ninu ipade onjẹ, iyan a ṣe alagá, àmàlà a ṣe igba keji, iresi ni igba kẹta, ẹkọ ni aṣãju, ó si jẹ onirẹlẹ, ṣugbọn ọ̀bẹ̀ ni ọlọpa, on atọ́kùn okele, gbati iyan gbeyawo, ọbẹ ila ni yawo, gbati àmàlà l'obinrin, ewẽdu l'obinrin, ẹfọ l'aya àkàṣù, mọinmọin arẹwa, olufẹ ẹkọ mimu, dòdò nã ko rẹhin, bãlẹ igberiko, dundu kò kere, o jọba si ileto, Kakanfo ni 'bẹpẹ, ọgẹdẹ wẽrẹ l'aṣipa, igbati gãri nṣọdun, o pe







Ha ! Ọba Edidarẹ, malũ ni ẹ npe ni ẹṣin !

ẹja si pade, o pe ẹran si pade, o pe edé si pade, o pe ila si pade, o tun pe 'wẽdu si pade, bẽni o gberaga bẹ ni, ajẹjù kò sunwọn, iwọntunwọnsi l'o dara. Alagbara ni ata, alubọsa gbajumọ, bọkini tomati, ọlọrọ̀ ni ẹgunsi. Leri gbogbo iwọnyi, onjẹ dãdã, omi dãdã, atẹgùn dãdã, ni nṣe ara dãdã.'

"Bayi ni awọn Èdìdàrẹ̀ ka igbagbọ wọn lori onjẹ. Nigbati nwọn nka igbagbọ yi ẹnikẹni kò sọrọ kanṣoṣo ṣugbọn were ti nwọn ka a tan ni nwọn ti tun bẹrẹ ariwo. Awọn Edidarẹ bu ọla fun onjẹ ju ọba wọn lọ. Mo si fẹ ki ẹ ṣakiyesi pe õtọ ni gbogbo nkan ti nwọn sọ nipa onjẹ, ó fi han ni pe nkan ti enia ba nfẹ lati mọ̀, yio mọ ọ, awọn Edidarẹ gọ̀ nwọn bajẹ ṣugbọn nwọn kọ ẹkọ nipa onjẹ.

"Nwọn ko da ẹjọ pupọ lọjọ ti mo nsọ yi, ṣugbọn eyiti nwọn

si da, ẹjọ ọba pãpã ni. Ọkunrin kan gba mẹta ninu awọn iyawo ọba, awọn mẹtẹta si wa siwaju ọba, nwọn nro ẹjọ ara rẹ̀ fun u, nwọn si nbu u ṣàkà bayi loju mi, bẽni on ni yio da ẹjọ, o si yà mi lẹnu pe oju gbogbo wa bayi ni ọba ṣe nbẹ̀ wọn ki nwọn pada si ọdọ on. Bi o ti wi bayi ni ẹnikanṣoṣo ti o gba iyawo mẹtẹta bọ siwaju ọba ti ó nbu ọba pe nwọn ko ni pada, owo ọba ni nwọn mã san. Igbati ọba ri i pe ati pada jẹ iṣoro, ó gba kọbọ kõkan lori iyawo kõkan, gbogbo rẹ̀ jẹ tọrọ—bẽ l'o si wa jẹ pe tọrọ ni owo Obinrin mẹta ni ilu awọn Ẹdìdàrẹ́.

"Ẹjọ ti nwọn ṣe tẹle eyi, ẹjọ ọba na ni. Ẹnikan wipe baba ọba, eyini ni Omugọdimeji, ti jẹ on ni owo kan ki o to ku, pe owo nã jẹ kọbọ mẹrin o si fi jàgùdàpãli le e pe afi bi ọba ba san owo nã fun on ni werewere. Ọba ba mu tọrọ ti o gbà lori awọn iyawo rẹ̀, o ko o fun u, owo wa ku kọbọ kan lati san, oju mi bayi si ni ọba ṣe nwa owo ya ti ko ri ẹni ya on ni kọbọ, oju mi bayi nã si tun ni ẹniti o ni owo yi ṣe lọ si ọdọ akọwe Igbimọ ti ó ni ki ó fun on ni iwe ẹjọ ki on fi ba ọba ṣe ẹjọ nã, oju mi nã bayi ni akọwe si fi fun u ni iwe. Nigbati nwọn fun ọba ni iwe ipẹjọ, ọba dọbalẹ lãrin Igbimọ, o bẹ ọkunrin na. Onitọhun si wi fun u pe on fun u ni ọjọ mẹta ki o fi mã wa owo nã kiri, ati pe bi ko ba ri i, on o pe e ni ẹjọ ẹ̀wọ̀n. Bayi ni mo de ilu awọn Ẹ̀dìdàrẹ́ ni ibiti nwọn ti npe ọba l'ejọ kọbọ kan.

"Nigbati a kuro ni Igbimọ, mo pada lọ si ibudo wa, mo rohin ohun ti mo ri fun gbogbo wọn.

"Ṣugbọn o yà mi lẹnu pupọ bi Alaiyeluwa Ọba Ọmugọdimẹta ṣe huwa lẹhin eyi. Ṣe ẹniti o ba nri emi ati on bi a ti jọ nrin ko ni ṣai ni ero pe a nbẹrẹ ọrẹ. Ṣugbọn, bẽ kọ, Omugọdimẹta ko mọ iyi mi rara. Ko si jọ mi loju pe ó ri bẽ, nitori bẽ ni awọn ẹlomiran wà ni ode aiye ti nwọn njẹ orukọ miran ṣugbọn ti iwa wọn ba ti Omugọdimẹta mu. Awọn eleyi ni ẹni egun, nwọn ṣẹ̀ si Olodumare, nwọn si ṣẹ̀ si enia pẹlu, bi ẹnikan ba rẹ ara rẹ̀ silẹ, dipo ki nwọn tubọ mã gbe e ga, gẹgẹ bi aṣẹ ọmọ Olodumare ni ijọsi, nwọn a fi oluwarẹ̀ si abẹ atẹlẹsẹ wọn, nwọn a gbe ẹsẹ wọn soke, nwọn a gbe e le oluwarẹ̀ lọrùn dipo gbigbega, nwọn a mã fi iwọsi lọ ọ. Iru awọn ẹni bẽ ko ni le duro lãrin awọn ero iwaju, ãrin ero ẹhin ni nwọn o mã wà lailai.





"Kini mo mã ri, Omugọdimẹta lọ ṣe ofin ti o fi han gbangba pe emi ati awọn ẹlẹgbẹ mi ni o nfẹ ṣe ni ibi awọn ofin nã ni iwọnyi:

"'Ofin Kini: Ẹnikẹni ti ó ba ri Irinkerindo nilati nà a ni igi lẹhin ọrùn, ẹniti o ba ri ọkunrin nã ti ko fọ ọ ni kumọ dãdã, oluwarẹ̀ ibã ṣe ọkunrin, ibã ṣe obinrin nilati san kọbọ marun.'.

"Mo fẹ ki ẹ wo bi ikorira nã ti to, ọba ti nwọn ni ki o san kọbọ kan ti kò ri, wa sọ pe ẹniti kò ba fọ emi ni kumọ dãdã nilati san kọbọ marun, owo obinrin marun ni ilu Edidarẹ!

"Ofin meji ti o ṣe ni o ba wa wi, ekeji si ni eyi: 'Alejo k'alejo ti o ba wọ ilu ko gbọdọ jẹ onjẹ ara rẹ̀, onjẹ awọn Edidarẹ l'o nilati rà jẹ, kò gbọdọ mu omi ibomiran, omi awọn Edidarẹ l'o nilati mu, ko gbọdọ gbe ile ara rẹ̀, ile awọn Edidarẹ l'o nilati gbe. Ẹniti o ba lu ofin yi yio wọ ẹwọn iṣẹju mẹwa.'

"Igbati Omugọdimẹta kọ awọn ofin yi tan o pari wọn pẹlu ọrọ wọnyi: Emi, Ọba Nla ti o ju gbogbo ọba lọ, Alaiyeluwa Omugọdimẹta, ọba Edidarẹ, ti Ilaburu bi fun Omugọdimeji, baba Danasungbo, mo fi ọwọ ati ẹsẹ mi, oju ati imu mi, ori ati ọrun mi, inu ati ẹhin mi, ori ahọn ati iho imu mi si iwe yi, ni ọjọ kẹsan, oṣu kẹfa, ni ẽdẹgbẹwa ọdun o le mejileladọta lẹhin iku Oluwa wa.'

"Nkan ti mo sa fẹ ki ẹ mọ ni pe a nilati ba awọn Edidarẹ jagun gãn le ori ofin yi, nko ni le rohin ogun nã fun yin, nitori akoko nlọ, ṣugbọn a ṣẹgun, nwọn tũba fun wa, nwọn ni awọn di tiwa.

"A ba awọn ijoye ilu nã ṣe adehun, nwọn si fi ọwọ si iwe pẹlu wa pe awọn di tiwa. Ohun kini ti a kọ ṣe ni pe a wa ọpọlọpọ ọkọ ati ada pẹlu ãke a ko o fun wọn ki nwọn bẹrẹsi ṣe iṣẹ ati tun ilu ṣe. Nwọn ro oko gbogbo ti o wa ni igboro, nwọn ṣe oju ọna dãdã, a mu ki nwọn ṣe ile igbọnsẹ, gbogbo awọn igi ti o wa lãrin ilu ti o mu ki ilu dabi inu igbo l'a mu ki nwọn ge, nwọn tun odò gbogbo ṣe. A wa ọpọlọpọ ọṣẹ ati kaninkan, a fi fun wọn ki nwọn fi wẹ̀, a si ṣe ofin pe olukuluku nilati fi ara han ni bi o ba ti wẹ̀ tan. Bayi ni a tun ilu wọn ṣe.

"Mo ro pe ẹ o fẹ lati mọ bi a ti ṣe ọba wọn si, yala a fi ọba miran jẹ ni tabi a ko fi jẹ. A ko fi ọba miran jẹ, ṣugbọn ohun ti a ṣe ni pe a fi ẹnikan ṣe Gomina fun wọn lãrin wa, orukọ

ọkunrin nã ni Apata-igbẹhin ti o jẹ aladugbo Kumọdiran ni ile. A wi fun u pe ki o ṣe itọju ilu nã dãdã ati wipe awa o fi ibẹ silẹ ni ikawọ rẹ ki a lọ si Igbo Elegbeje. Igbati a ba npada bọ a ni ireti pe oju awọn Edidarẹ o ti la. Idi rẹ ti a fi fi Apata-igbẹhin ṣe Gomina ibẹ ni pe on jẹ ẹni lile, ko ni gba iwọsi fun awọn Edidarẹ, nitori nwọn kò gba oju bọ̀rọ̀. A tilẹ ṣe aniyan pe ki Apata-igbẹhin ṣú Ilaburu ni opó, ṣugbọn kò fẹ, a wi titi, ṣugbọn o kọ̀ jalẹ o ni kò wu on, ati pẹlu pe õrun ara rẹ ko iti itan, nigbati o kọja lọdọ on, o nrùn si on.



# ẸBỌRA IGBERAGA-IBANUJẸ ATI AHỌNDIWURA IYAWO RẸ̀

"A kuro ní ilu awọn Edidarẹ lẹhin ti a ti gbe eti ibẹ fun odidi oṣu mẹta gbako, a kọ ori si ọna wa. Ẹ má jẹki eyi yà yin lẹnu pe a pẹ tobẹ̃ ni ilu kan ti a ko lọ si ibiti nwọn ran wa. Ọba pãpã ti fun wa ni aṣẹ bẹ̃ ki a to kuro ni ile, o ti wi fun wa pe bi a ba de ibikibi ti a ri i pe ohun ti a nfẹ ṣe yio gba ni to oṣu mẹfa tabi ju bẹ̃ lọ ki a maṣe kanju, ki a ṣe e dãdã.

"Irinajo wa dara lẹhin ti a kuro ni ilu awọn Edidarẹ a ko si ri nkankan titi a fi de inu igbo nla kan bayi ti orukọ rẹ̀ njẹ Aginju Babaloriṣa. Igbati a de aginju yi l'o tun di ki a mã ri awọn iwin.

"Ng o sọ nkankan ti a ri ni oru ọjọ kan fun yin: o ṣe ni, emi tilẹ sun lọ, ni awọn enia mi lù mi pẹpẹ lãrin oru ti nwọn ji mi. Nigbati mo wò yika, ilẹ ti ṣu bamubamu. Mo bẽre idi rẹ̀ ti nwọn fi ji mi, nwọn ni ki nfetisilẹ nitori awọn ngbọ ohùn ti ko jọ ti ara aiye ti o dabi ohùn ẹgbẹgbẹrun awọn ero ọja ti nwọn nho yànmù leti ẹni. Lõtọ nã, mo fetisilẹ, mo si ngbọ ohùn awọn ẹranko inu igbo ati awọn ejo inu aginju, awọn igi ati awọn ọpẹ, eweko ati itàkùn, dukia gbogbo ti mbẹ ni ori oke ati awọn ohun alumọni ti o wà ni isalẹ ilẹ, awọn ẹja inu omi ati awọn kokoro ori ilẹ—gbogbo nwọn nkigbe nwọn nwi bayi pe, 'Lọ! Lọ! Lọ! Jade! Jade! Jade! Má duro ti wa, má duro ti wa, awa ko fẹ ọ, awa ko ba ọ ṣe ajọpin, Igberaga, abawọn aiye, Igberaga, ifasẹhin ọmọ enia, Igberaga, má ko tirẹ ràn wa, mã lọ, mã lọ, mã lọ, jọwọ mã lọ o: —: —: — O; jọwọ mã lọ o: —: —: — o; jọwọ mã lọ o: —: —: — o.

"Bayi ni mo gbọ, ṣugbọn aiya mi kò ja ju bẹ̃ lọ, nitori lati igbati mo ti di olori ni mo ti pinnu pe nko ni bẹru mọ, nitori bi olori ba nbẹru jù, ko ni le ṣe alakoso awọn ọmọ ẹhin, bi aṣãju ba ba ẹsẹ rẹ̀ sọrọ, awọn ero ẹhin yio sare tagbaratagbara.

"Mo rọra dide lori ibusun mi, mo nwo ibiti mo ti ngbọ ariwo



5



Igberaga-Ibanuje ati Ahọndiwura iyawo rẹ.

yi. Nigbati o ṣe, mo ri imọlẹ nla kan ti ko yatọ si õrun gangan ti o ran yi ibi ribiti kan bayi yipo ẹnu ibiti õrun ẽmọ yi ran si to ẹsẹ bata mejila ni ibú o si to bẽ ni gigun, gbogbo iyoku lẹhin õrun birikiti yi wà ni okunkun biribiri.

"Nigbati mo wo ãrin ibiti õrun yi wà mo ri awọn iwin meji, ọkan jẹ ọkunrin ekeji si jẹ obinrin. Eyi ọkunrin de fila kan ti o fi ara jọ ade ti o nkọ mọnamọna bi okuta diamondi, ẹwu rẹ jẹ agbada nwọn si ge onirũru okuta olowo iyebiye pẹlẹbẹ pẹlẹbẹ nwọn fi ṣẹ ọna si i lara, gbogbo wọnyi ndan gbinringbinrin bi igbati alagbẹdẹ pataki ba ṣe ohun ọṣọ didara fun gbajumọ obinrin. Ati ṣokoto, ati ẹwu, ati fila iwin yi ri jingbinnì kanlẹ, bi on ba si ti nrin, nwọn ndun jinwinjinwin bi igbati awọn abọriṣa ba nlu ilu agogo ijo oriṣa wọn.

"Eyi obinrin dara tobẹ gẽ, o ro aṣọ ilẹkẹ wẽrẹ. Ko si iyatọ





lãrin obinrin yi ati awọn ọmọ araiye bi ko ṣe ahọn rẹ ti ó gùn rekọja ti o tayọ ẹnu ti ó ṣàn si igba aiya rẹ titi o fi kan a ni dodo.

"Bì awọn iwin meji yi ti nsunmọ wa ni imọlẹ nla nã nba wọn bọ lọdọ wa. Bi mo si ti ri i pe nwọn nsunmọ wa, mo dide duro mo ke ni ohun rara mo ni, 'Alafia ni ẹnyin nba bọ tabi kùmọ?' Eyi ọkunrin si da mi lohun o ni, 'Alafia ni'.

"Ṣugbọn mo ṣakiyesi pe bi nwọn ti nbọ ti nwọn wọ aṣọ didara to nì, ẹkun ni awọn mejeji nsun. Mo ba tun sọrọ mọ ni, 'Kini idi rẹ ti ẹ fi nsọkun ninu aṣọ jingbinni iru eyi?'

"Lẹhin nã ni iwin yi bẹrẹsi ọrọ isọ o ni,

"'Emi ni Igberaga-ibanujẹ, ọmọ Imọlẹ on Okunkun, ti ngbe ipade aiye on ọrun. Baba ni Imọlẹ jẹ fun mi ṣugbọn Okunkun ni iya mi. Iya mi ni mo jọ, nko si fi ibikan jọ baba mi. Gẹgẹ bi itan nã ti lọ, ẹrú ni iya mi jẹ, baba mi ni o si mu u loju ogun, lakoko ti ija de lãrin awọn ara ode ọrun ati Eṣu, ti Eṣu duro gẹgẹ bi Olori ogun lati da oju ija kọ Ọlọrun Ọba. Baba mi nja fun Olodumare, ṣugbọn iya mi ni iyalode ti nwa onjẹ fun awọn ọmọ ogun Eṣu lakoko ija nã. Ija nã pọ gidigidi. Ṣugbọn, asẹhinwa asehinbọ, Olodumare ṣẹgun, eyi l'o si mu ki a le Eṣu kuro ni ode ọrun ti o fi di pe o ngbe ọrun Apadi di oni oloni. Ni ọdun kẹdọgbọn ti nwọn bi mi ni mo fẹ wunndia kan lati ilu iya mi, on ni o si duro tì mi yi, Ahọndiwura ni orukọ rẹ njẹ, on si ni akọbi ọmọ ti Ajakalẹarun bi fun Iku ni ilu iya mi.

"'Ni ọjọ igbeyawo wa, gọngọ sọ ni ipade aiye on ọrun. Ọjọ nã ni baba mi fun mi ni ẹwù imọlẹ, o wipe: "Ibikibi ti iwọ ba nlọ, ibã ṣe ọsan, ibã ṣe oru, o kò ni rin ninu okunkun lailai". (Gbogbo awọn maleka si dahun pe "Amin".) Iya mi pẹlu fun mi ni ẹbun, ó fun mi ni agbádá nla ti iwọ ri l'ọrun mi yi, isalẹ apoti Eṣu ni nwọn si ti mu u jade, gbogbo awọn ara ode ọrun a mã pe agbada nã ni "Ẹwu Igberaga". Õtọ nã si ni, nitori ati ọjọ ti ẹwu yi ti de ọrun mi ni inu mi ko ti dun mọ, bẽni nko le bọ ẹwu nã kuro lọrun mi, iya mi ti wi fun mi pe bi mo ba mã bọ ọ, o di ọjọ ti mo ba ri ọmọ araiye ti yio ran mi lọwọ nipa rẹ. Emi pãpã mọ pe lati ọjọ ti mo ti wọ ẹwu nã ni mo ti di onigberaga, nkan mi ni o mã ndara loju mi, mo nhuwa bi ẹni pe tani mã mu mi, irin ẹsẹ mi, ọrọ ẹnu mi, iṣe

mi si ẹnikẹni, ti igberaga ni. Ojojumọ lati ọjọ ti mo ti wọ ẹwu yi ni awọn ẹbọra ode ọrun nṣe nkan ti o dara ju temi, bẹ̃ni nko fẹ ki nkan ẹnikẹni gbé temi, eleyi a si mã bà mi ninu jẹ, bi mo ba ti nri ilọsiwaju wọn ni inu nbi mi, emi a si mã sọkun titi lojojumọ ọjọ aiye mi.

"'Iyawo mi pẹlu, ko yatọ si mi ju bẹ̃ lọ, bọkinni on ọlọrọ ẹgbẹra, ọbun on aṣiwere ọkanun, ọkanjua on ole, dẽdẽ ni nwọn ja si. Ni ọjọ igbeyawo wa, Ajakalẹarun ti iṣe iya on gba agbara lọwọ Eṣu, o fa ahọn iyawo mi yọ, o si fi omiran pãrọ rẹ̀, eleyini nã ni ahọn gbõrọ ti iwọ ri yi, ti o tayọ ẹnu ti o si gùn de iyawo mi ni dodo. Ko si obinrin nã lode aiye tabi lode ọrun ti o le ro ẹjọ ẹlẹjọ kiri to bi iyawo mi yi, nitori ahọn abami gigun yi a mã tikararẹ̀ ro ẹjọ laijẹ̀pe iyawo mi ran a, ahọn nã a mã gbọran bi enia, ko si si ibikibi ti ẹnikẹni ti le sọrọ wa loni ti ahọn yi kò ni sọ fun wa. Ọrẹ ti ko jẹ rohin ẹniti o sọrọ ọrẹ on ni rere afi ẹniti o bu u, aya ti ko jẹ rohin ẹniti o yin ọkọ on afi ẹniti o bu u, iru awọn bawọnyi ni adijãlẹtakete, ọbaiyejẹ enia. Ipo yi ni ahọn ẽmọ yi duro si fun iyawo mi, ahọn ti ó gbà lọwọ Ajakalẹarun ti iṣe iyawo Iku lọjọ igbeyawo wa. Ẹlẹda fi ọmọ jinki wa, a bi ọmọ meji, ọkan ọkunrin, ọkan obinrin. Eyi ọkunrin ti o jẹ akọbi ni orukọ rẹ̀ njẹ Iṣubu, orukọ abikẹhin ti o jẹ obinrin si ni Iparun. Awọn mejeji ti gbeyawo, ọmọbinrin ti Iṣubu tilẹ kọ fẹ ni ẹniti orukọ rẹ̀ njẹ Itijuparẹ ti o jẹ ọmọ olorukọ mi ni ọrun Apadi, eyini ni pe baba rẹ̀ nã a mã jẹ Igberaga-ibanujẹ, ṣugbọn nigbati a lọ tọrọ ọmọ nã ni nwọn wi fun wa pe ibatan wa ni iya rẹ̀ nitori ile kannã ni nwọn gbe bi Ahọndiwura ti iṣe iyawo mi ati iya ọmọde nã. Nigbẹhin ṣa, Iṣubu fẹ ọmọbinrin kan ti orukọ rẹ̀ njẹ Ibanujẹ-ode. Eleyini nã ba wa tan diẹ ṣugbọn itan gigun ni, nitori baba rẹ̀ ni Aisanfẹhinti ti ó jẹ ọmọ Aimọkan ti o ba iya mi, Okunkun tan. Ọkọ Ipàrun ni Jagudapãli ti obinrin kan bayi ti orukọ rẹ̀ njẹ Ẹ̀tẹ́-ile bi fun Biliṣi.

"'Leri gbogbo eyi, iwọ ọmọ enia, jọwọ mo bẹ̀ ọ gidigidi, ba mi bọ ẹwu igberaga ọrun mi, nitori ko jẹki inu mi dun rara. Ko si jẹki inu Olodumare dùn si mi bẹ̃ni ẹniti inu Olodumare ko dun si kan ijangbọn. Ran mi lọwọ, jọwọ, ọmọ enia, ba mi bọ ẹwu igberaga.'





"Bayi ni iwin nã sọ, lẹhin eyi, mo wo oju sanma mo ra ọwọ si oke mo ke pe Ọlọrun Ọba pe ki ó maṣe binu si mi pe mo fẹ ṣe õre fun iwin nã, kàkà bẹ̃, ki ó ka a kun iṣẹ rere kan pataki ti mo ṣe ni ode aiye, mo ba pe Igberaga-ibanujẹ ki ó sunmọ mi, lẹhin ti ó ṣe eyi mo wo ẹwu nã bi o ti ri, mo ri i, o lẹ̀ mọ ọ lara tipẹtipẹ, mo tilẹ kọ ṣebi ẹ̀wù nã lẹ̀ mọ ọ lara ni, ṣugbọn ko ri bẹ̃, irun ara iwin nã gùn pupọ on l'o si wé mọ ẹwu nã. Mo ba pe awọn enia mi, mo ni ki olukuluku mu abẹ ninu apo rẹ̀ ki a ge ẹ̀wù nã wẹlẹwẹlẹ kuro lara iwin nã. Igberaga-ibanujẹ dubulẹ, bi ogoji enia bẹrẹsi ṣiṣẹ si ara ẹwu rẹ̀ a ge ẹwu nã wẹlẹwẹlẹ ti a fi bọ ọ kuro lara rẹ̀ tan po.

"Igbati a ṣe eleyi tan, inu iwin nã dun pupọ, ṣugbọn o ku bi a o ti ṣe ahọn iyawo rẹ̀ gigun gbõrọ. Ibiti mo ti nronu eyi ni mo ti ri omi kan ti ó kán silẹ lara ẹ̀wù Igberaga-ibanujẹ, mo lọ si ibiti ẹ̀wù nã wà, nigbati mo si fi ọwọ kan omi nã o dabi afárá oyin. Ṣugbọn bi mo ti npada ti ibiti akisa ẹ̀wù nã wà bọ̀, mo yà si ọdọ Ahọndiwura, mo fi ọwọ kan ahọn rẹ̀ gigun, bi omi ti mbẹ lọwọ mi si ti kan ahọn nã ni mo ri i ti o nká wọ inu bi ẹ̀wọ̀n agogo. Nko si duro pẹ titi ti mo ri i ti ahọn yi sa wọle tan ti ahọn miran yọ dipo rẹ̀ ti o ṣe iwọ̀n ẹnu.

"Bayi ni emi ati awọn ẹnikeji mi ṣe iranlọwọ pataki fun Igberaga-ibanujẹ ọmọ Imọlẹ on Okunkun, ti ngbe ipade aiye on ọrun ati iyawo rẹ̀, Ahọndiwura, ti iṣe iya Iṣubu ati Iparun, ọmọ Ajakalẹarun on Iku, ti iṣe iya ọkọ Ibanujẹ-ode.

"Nigbati ohun gbogbo pari tan, isẹ̀lẹ̀ nla sẹ̀, ilẹ bẹrẹsi mì, àrá nsan, igbo npariwo, awọn igi ati ọpẹ si bẹrẹsi ke wipe: 'Ẹ ṣeun, ẹ ṣeun, a dupẹ, a dupẹ, a dupẹ, ọna yin yio dara, ile yin yio sunwọ̀n, ẹ ṣeun, A! Ẹ ṣeun, ẹ ṣeun o etc.'

"Gbogbo iwọnyi ṣẹlẹ̀ loru, igbati awọn iwin meji yi dupẹ lọwọ wa ti nwọn lọ tan awa nã sun orun diẹ si i, ko si pẹ lẹhin eyi, ilẹ mọ.

"Igbati o tun di ọsan ọjọ keji ni nkan bi agogo mejilã a tun ri nkan abami miran.

# A FI OJU WA RI ỌRUN APADI

"Bi a ti de ibikan ti o dakẹ minimini bayi, ti igbo ibẹ dí ti o dudu mirinmirin ni a ri iwin kan ti o nbọ, o dabi ọba gãn, igbati a si kọ ri i, a ke 'Kabiyesi', a ti gbagbe pe Aginju Babaloriṣa ni a wà, bẹ̃ni ko si ibiti ẹbọra nã fi yatọ si ọba. Fila ori rẹ̀ dabi ade, bata ẹsẹ rẹ̀ dabi bata ẹsẹ awọn alagbara, bẹ̃ni ẹwu ọrun rẹ̀ ko yatọ si ti ọba ti o ti gba ade lati ọwọ Oduduwa, ọpọlọpọ awọn iwin miran ni ó tẹle e, ọkan ninu awọn iwin nã si gbe apoti kan le ori, o nru ù tẹle e. Igbati gbogbo awa ọdẹ dọbalẹ ti a ki iwin pataki yi, o dahun o ni,

"'Ibo l'ẹ nlọ bawọnyi, ẹnyin ọmọ enia?'

"Emi nã fesi mo ni, 'Kabiyesi, a nlọ si Oke Ironu ti mbẹ ninu Igbo Elegbeje, ki ọgbọn ba tubọ wọ inu ilu wa, ki oye ba tubọ de ibẹ. Ṣugbọn emi bẹ̀ yin tọkantọkan, ẹ maṣai sọ ẹni ti ẹnyin jẹ, ẹ má si ṣai sa ipa yin fun wa ni ọnakọna ti ẹ ba mọ ti o le jẹ iranlọwọ fun wa.'

"Nigbati iwin nã gbọ bayi, o bẹrẹsi sọrọ o ni:

"'Emi ni Adeforiti, ẹbọra ti ile rẹ̀ mbẹ ni àjùlé ọrun, orukọ ti Olodumare fun mi ni yi, nitori emi ni o ni iforiti julọ lãrin ẹda. Ọpọlọpọ nkan rere gbogbo ni iforiti si ti mu ba mi. Ẹda ti ko ba ni iforiti, yala ni inu aiye tabi ni ode ọrun, ẹda lasan ni. Ni akoko ti iwin buruku kan ni eti ode ọrun ba ọmọ rẹ̀ ja, ti ko si ẹniti o le la ija nã, emi ni mo pari ija wọn. Orukọ iwin buruku yi ni Ibinu-ẹkun ti iṣe ibatan Igberaga-ibanujẹ ni idi iya. Ibinu-ẹkun ni ẹniti o le binu julọ lãrin ohun gbogbo ti mbẹ lọju omi tabi ni isalẹ ilẹ, ti ó wà lofurufu tabi ni iyangbẹ ilẹ. Ni akoko ija yi, gbogbo awọn ẹbọra ode ọrun bẹ ẹ, ṣugbọn on kò gbọ, ó le ọmọ rẹ̀ wa si ile aiye ki ọmọ nã ba le ni ipin tirẹ̀ ninu ọkẹ aimoye ibanujẹ ti ntẹle ọmọ enia kiri titi ọjọ aiye wọn. Mo dide mo lọ si ile Ibinu-ẹkùn lati yi i lọkan pada kuro ninu ero yi, ṣugbọn pẹlu kùmọ̀ ni on fi le mi jade. Ni ọjọ keji, mo tun lọ, ṣugbọn bi ó ti fi oju kàn mi ni o yin ibọn, diẹ l'o si kù ki ibọn nã bà mi. Mo tun lọ





ni ọjọ kẹta pẹlu, ṣugbọn o bu mi lati ẹsẹ mi de ori koko, o fa ada yọ, ni igbẹhin o fi ada le mi de ile mi koko. Sibẹ mo lọ ni ọjọ kẹrin, ṣugbọn ó fi ògèdè pe aja Eṣu lati isalẹ ilẹ ni inu okunkun biribiri ki aja nã ba wa pa mi jẹ, ṣugbọn ọwọ aja yi ko tẹ̀ mi, mo si tun mu sũru mo lọ ba Ibinu-ẹkun ni ọjọ karun, ṣugbọn ki nto de ọhun, ó ti mọ pe mo nbọ o si ti kó onirũru awọn ẹda ọrun ti iwa wọn ba tirẹ̀ mu silẹ dè mi, bi mo ti yọ l'ọkankan ni mo ri gbogbo wọn pẹlu ohun elo ija ti nwọn nfẹ fi ṣe mi ni ijamba, ṣugbọn emi duro ni okẽre mo si bẹ Ibinu-ẹkùn tãnutãnu pe ki o ṣe aforiji fun ọmọ rẹ̀, lẹhin eyini, emi nã pada lọ si ile mi. Ṣugbọn bi ilẹ ọjọ keje ti nmọ hai ni mo tun dide, mo ba ile Ibinu-ọkun lọ, àṣé on ti ni ero pe mo le wa ba on, o si ti dẹ pakute si ọna de mi ni oru. Riri ti o ri mi ni inu bi i ti o nsare bọ wa pade mi. O gbagbe pe on ti dẹ pakute si oju ọna dè mi, ibiti ti o ti ni ki on kọja ni oju ọna wa ba mi ni pakute ti mu u, ọran mi wa tubọ le, ijangbọn nle mi bọ mo pade ijangbọn lọna, ati kuro lọwọ ijangbọn di ijangbọn fun mi. Mo yara bẹ awọn iwin ti mbẹ ni agbegbe ibẹ ki nwọn ba mi tu Ibinu-ẹkun silẹ, ki nwọn si to ṣe eleyi tan mo ki ire mọlẹ mo sare tagbaratagbara.

"'Igbati nwọn tu u silẹ tan, o bẹrẹsi wa mi kiri, o ranṣẹ lọ si ile aiye, o ran lọ si àjùlé ọrun o wa mi de ọrun Apãdi pãpã, ṣugbọn ko ri mi mo fi ara pamọ patapata nitori mo ti mọ pe mo da ọran ti o kọja ọran, mo wo kiniun loju, mo ṣe "Siọ" si ijapa, mo tẹ ọka ni iru mọlẹ, mo mu obinrin jade ni ọjọ ti orò gba ode. Nitori ẹṣẹ mi nla nì, mo ba inu iho ilẹ lọ ọgọta ọjọ ni mo si gbe lọhun ki nto jade.

"'Ni opin ọgọta ọjọ, mo jade. Jijade ti mo si tun jade pẹlu, ile Ibinu-ẹkun ni mo kọ ori si. Akoko yi gãn ni oloriburuku yi wa mu mi, o le mi o ba mi nibiti mo ti nsalọ. Nigbati o si mu mi, o fi okùn si mi ni ẹsẹ o si so mi mọ igi rẹ̀gẹ̀jì kan ti mbẹ ni ita rẹ̀, mo kọ ori si odo, mo nfì dirodiro, on si gbe ẹru paṣan jade, o bẹrẹsi fà wọn yọ ni ọkọkan o si nnà mi. Nigbati o ṣe ti mo ri jọwọlọ ti mo si nku lọ, o tu ẹsẹ mi kuro lara igi o si gbe mi jù silẹ o ṣebi mo ti ku ni. Lẹhin eyi o wọ agbala rẹ̀ lọ o si bẹrẹsi wa igi lati fi da ina sun mi, ṣugbọn ki ó to pada de, atẹgùn ti fẹ si mi mo si ti dide, mo salọ.

" 'Igbati mo de ile mi, mo ṣe itọju ara mi daradara, ki ilẹ si to mọ, ara mi ti le.

" 'Mo tun dide ni owurọ ọjọ keji, ó di ile Ibinu-ẹkùn. Igbati mo yọ lọkankan, ti ó ri mi, agara ti da a, o ju ọwọ si mi ki nmã bọ̀, emi nã si nlọ, mo wọ inu ile rẹ̀ pẹlu ibẹru ṣugbọn laipẹ ni mo ri i pe èrè iforiti mi ti de, mo ti ṣẹgun, mo ti gun oke de ori, mo ti ṣe dãdã ninu idanwo, mo ṣẹgun Ibinu-ẹkun patapata, oju rẹ̀ rọ̀, mo pe ọmọ rẹ̀ wọle, o tũba niwaju baba rẹ̀. Bẹni mo pari ija lile nã.

" 'Gbogbo bi mo ti nṣe ni Olodumare nwo mi, igbati mo si npada bọ wa si ile, mo gbọ ohun kan lati oke wipe, "Nitori iwọ ṣe eyi, a ki yio pe ọ ni orukọ rẹ atijọ mọ, Adeforiti ni a o mã pe ọ, nitori iwọ ni iforiti ju awọn ẹda iyoku lọ."

" 'Ati ọjọ yi wa ni Ẹlẹda ti fi ohun gbogbo tẹ mi lọrun ni ile mi, ṣugbọn, iwọ ọmọ enia. Bi mo ti ri ọ loni, inu mi dun jọjọ, mo si fẹ ki o wi fun awọn enia rẹ, ki ẹ tẹle mi, ki ẹ wa lọ mọ ile mi.'

"Nigbati o wi bayi, mo tọrọ aye lọwọ rẹ̀, ki ó fun mi ni aye diẹ ki emi ati awọn ẹgbẹ mi lọ ronu nipa ọran nã, ó si gbà bẹ̃ fun mi.

"Igbati a bila sẹhin diẹ bayi ti a joko ni ibikan ti a ṣe àṣàrò lori ọran nã, ogunlọgọ ninu awọn ọdẹ ni nwọn fẹ pe ki a ba a lọ, ọpọlọpọ ni awọn ko de ile iwin ri, awọn fẹ mọ bi ile wọn ti nri, ati pãpã pe eleyi jẹ ọlọla lãrin awọn ẹmi wọnni.

"Nigbati a pada tọ ọ lọ mo wi fun u pe awọn enia mi ti pinnu ati ba a lọ. A ba tẹle e. A ko rin tobẹ̃ nigbati ó dede duro ti o ba ilẹ sọrọ o ni, 'Iwọ ilẹ, la ẹnu fun mi, mo fẹ lọ si ile iya mi.' Bi o ti wi bayi, pẹ̀rẹ́ ni ilẹ là ti a si ri àtẹ̀gùn didara kan bayi ti o ba iho ilẹ lọ, gbogbo wa sa bẹrẹsi tọ àtẹ̀gùn yi ba isalẹ lọ.

"Igbati a de ọhun, a ba ara wa ninu ãfin nla kan ti o dara tobẹ̃ ti kọ si ọrọ lati fi ṣe apejuwe ibẹ, àṣẹ ile rẹ̀ ni eyini. Igbati a de ọhun, o mu wa tọ iya rẹ̀ lọ, o fi wa han a, iya rẹ̀ nã si ki wa dãdã, iya rẹ̀ nã sanra diẹ gbogbo ara rẹ̀ si ndan, ó mọ tonitoni ṣugbọn oju rẹ̀ kò dabi oju enia nitori ṣe l'o ri rubutu bi oju igbá tabi oju ife ẹmu, oju meji ni, ṣe ni awọn oju meji





nã si nyi soke sodo lẹ̀kọkan, o ba ni lẹru gidigidi. Ṣugbọn ehin rẹ̀ funfun ti nko ri iru rẹ̀ ri, o dara, o ri wẹ̀rẹ.

"Lẹhin igbati a ki iya rẹ̀ tan, o mu wa lọ si ibiti a mã gbe, ó ni ki a da ara wa si ọna mẹrin, a si ṣe bẹ̃ nwọn si kó ìdá kọkan pọ si inu iyãra nla kọkan kakiri. Ṣugbọn bakannã ni gbogbo iyãra nla nla nã ri.

"Lọjọ ti mo ti de inu aiye nko gbadun to bi mo ti gbadun ni ile iwin yi ri. Idi rẹ̀ ni pe ohunkohun ti a ba nfẹ nbọ siwaju wa ni, ko si pe a nbẽre lọwọ ẹnikẹni ki a to ri i. Bi a ba wipe iṣu nwu wa jẹ, were ni iṣu a bọ silẹ niwaju wa ti yio mã hõru ninu awo, bi a ba wipe irẹsi nwu wa jẹ on ọbẹ adiẹ, ki a wo iwaju ki a ri irẹsi pẹlu adiẹ ti nwọn ti din ti o gbẹ tẹkitẹki ni. Igbakan ti mo wipe ẹmu nwù mi mu were ni mo ri ẹmu ogidi niwaju ti o nru pata. Ko si pe a nwa nkan a kò ri rara.

"Nigbati o di alẹ ọjọ ti a de ibẹ yi, iwin nã wi fun ni pe on ni iṣẹ kan lati ṣe ati pe on si fẹ ki a ran on lọwọ lati ṣe ninu iṣẹ nã. Igbati a bẽre iṣẹ ti o nfẹ ṣe yi ó ni on fẹ kọ ile 'Igbega-ọrun'. Ile yi jẹ ile ti Ẹlẹda ti nfẹ ki ọpọlọpọ ninu awọn ara ode ọrun kọ ati pe nitori ti ọpọlọpọ ti gbiyanju ti nwọn ko le kọ ọ on ti sọ fun Olodumare pe on fẹ kọ ile nã Olodumare ti gba fun on o si ti fi ilẹ ibiti on le kọ ile nã si han on, nitorinã on fẹ lọ bẹrẹsi mã ṣanko ki on ṣe diẹ ninu iṣẹ nã lowurọ ọjọ keji, inu on o si dun bi a ba le ba on ṣan diẹ ninu oko yi. A gbà pe a o ba a ṣiṣẹ rẹ̀.

"Nigbati o di owurọ ọjọ keji, nwọn gbe apoti kan jade, apoti ti mo sọ pe a ri pẹlu wọn loju ọna ni. Igbati nwọn si ṣi apoti yi nwọn kó ẹwu pupọ jade ẹ̀wù iṣẹ ni, nwọn si pin i fun gbogbo wa. Lẹhin eyi, nwọn kó àdá fun ni, a mura o di inu igbo ti Ẹlẹda pa laṣẹ pe ki Adeforiti ti kọ ile igbega-ọrun.

"A ṣan igbo gbogbo ti o wà ni ibiti a o kọ ile yi si a pada wa si ibiti a ngbe. Nigbati a o fi de ibẹ ni ọjọ keji, gbogbo igbo wọnni ti dide nwọn duro ṣanṣan, igi ti gbongbo rẹ̀ ti wú tun ri gbongbo mọlẹ, ewe ti o ja silẹ tun pada lọ si ori igi, bẹ̃ni awọn ẹka gbogbo pada lọ si ibiti nwọn ti wà ri. A tun mura, a nba iṣẹ nã lọ. A pari oko yi ki ilẹ to ṣu, a si fa gbongbo awọn igi ati ìtàkùn tu, a da ina ti igi iroko ti ó wà nibẹ ni ọrùn, a wu gbongbo awusa, a si to igi gbigbẹ yi ọganwo ka, a da ina

nla yi awọn igi buruku wọnni po. Eleyi ni a ṣe ti a pada wa si ile.

"Kutu hai owurọ ọjọ keji ni a tun lọ bẹ ibẹ wo. Nigbati a si mã dé ọhun, awọn eweko wọnni ti hù, ina ti a da ti ku, ohun gbogbo tun ti pada di bi ti atẹhinwa.

"Lẹhin eyi a bẹrẹsi wa awọn lebira kiri, awọn ara ọrun gãn. Adeforiti ni on ro pe afi awọn ara ọrun gãn ni yio le ba on ṣiṣẹ nã. Ó wa lebira titi kò ri, o ba lọ sọ fun iya rẹ̀ o ni, 'Iwọ iya mi tõtọ, mo ti gbiyanju bi o ti yẹ ki ngbiyanju to, ṣugbọn sibẹsibẹ nko le ṣan oko ti o wà ni ibiti ng o kọ ile "Igbega-ọrun" si, ẹ maṣe binu pe mo gbagbe ki nsọ fun yin ki nto bẹrẹ iṣẹ nã, ṣugbọn ẹ jọwọ iya mi ọna wo ni mo le gba ri lebira ti yio ba mi ṣiṣẹ nã ti ng o fi le kọ ile "Igbega-ọrun'"?

"Iya rẹ̀ wo o tãnutãnu ninu ile wọn, oju obinrin nã yi soke sodo o nkọ bi ìmọ̀nàmọ́ná oju ọrun o dahun o ni, 'Ọmọ mi, ọmọ mi, maṣe dawọle ati kọ ile Igbega-ọrun, awọn ti ọ jù ọ lọ ti gbiyanju bẹ̃ni nwọn ko le ṣe e, nitori Ọlọrun ọba nikan l'o mọ bi ile Igbega-ọrun yio ti ṣe dide, ṣugbọn nipa ti lebira, awọn wọnni ko si ni ihin, nwọn wà ni Ọrun Apadi. Afi bi o ba lọ si Ọrun Apadi ni o to le ri wọn. Bi o ba mã lọ, o nilati lọ gbe epo alafia ti mbẹ ni iyãra mi ki o fi pa ara, nitori ki ina Ọrun Apadi má ba le ṣe ọ ni nkankan, bi o ba si fẹ mu awọn ọrẹ rẹ lọ, awọn enia wọnyi, o nilati fun olukuluku wọn ni fila airi ti mbẹ ninu apoti nla ni àbáwọ inu iyãra mi kekere, ki nwọn de e nitori Eṣu ko gbọdọ ri wọn, ṣugbọn bi o tilẹ jẹ pe ẹnikẹni ko ni le ri wọn bi ko ṣe iwọ, sibẹ awọn nã nilati fi epo alafia pa ara. Bi o ba pinnu ati lọ dandan (nitori mo woye pe ọran nã wà lọkan rẹ pupọ). Igbati o ba de Ọrun Apadi gãn, mã lọ gãnran si ọdọ Eṣu ni inu ãfin rẹ̀. Ṣugbọn maṣe dọbalẹ fun u, bẹ̃ni iwọ ko gbọdọ ke "Kabiyesi", nitori ọjọ ti ọmọ imọlẹ ba tẹriba fun Eṣu ni aiye ọmọ nã pin. Iba ohun ti mo le sọ fun ọ ni eyi, ọmọ mi.'

"Adeforiti mura ati lọ wa lebira dandan o si wi fun wa ki a mura di ọjọ keji ki a ba ba on lọ ki awa nã tilẹ wo bi Ọrun Apadi ti ri.

"Igbati ilẹ ọjọ keji mọ, o gbe igo epo alafia jade, gbogbo wa fi ra ara, lẹhinnã o pin fila airi fun ni, a de e, ẹnikẹni ko si le





ri wa mọ afi on. Ẹ maṣe gbagbe pe Àjùlé Ọrun ni awa wà yi o, nitori ibẹ ni ile Adeforiti. Igbati a mura bayi tan, a mura, o di ọna Ọrun Apadi.

"Biatikuro ni Ajùlé Ọrun tan ti a fi agbegbe ibẹ silẹ patapata ti a fi ẹsẹ le ọna Ọrun Apadi, nkan ti o kọ ya ni lẹnu ni ẹbọ ti ó wà ni oju ọna ni apa ọtun ati apa osi lọ, ogunlọgọ wà ninu apãdi ti nwọn bu epo si, igbamiran odidi malũ a wà ninu epo, igbamiran nwọn a bu epo si ẹkọ tutu, igbamiran nwọn a ko ẹyọ owo si inu apãdi nwọn a bu epo si i, nwọn a la ifun adiẹ nwọn a rọ epo si i. Gbogbo ẹbọ ti ọmọ araiye nrú si Eṣu ni ikorita ni wọnni. Eyiti nwọn ba ru lojumọ a wà ni eti ọna ile Eṣu lọ, igbati Eṣu ati awọn ọmọ ogun rẹ̀ ba si fi mã jẹ ti ọjọ kan tan, ọmọ araiye a ti pese ti ọjọ keji silẹ, nitori eyi, apãdi pẹlu egungun ẹran a dabi okiti ọ̀gán si apa ọtun ati apa osi ọna lọ, nitori ọjọ si ti pẹ ti awọn ọmọ araiye ti nṣe wọnyi apadi pọ tobẹ̃ ti o jẹ pe nigbamiran ti enia ba wo apa ọtun a ri egungun ati apãdi lọ ni ogunlọgọ mẹ̃li, bi ó tun wo osi a ri i bakannã lọ.

"Igbati o ṣe ṣa, a de Ọrun Apadi ni ibiti Eṣu ti nṣe ọba wọn.

"Nkan kini ti o le kọ ya ẹnikẹni lẹnu nigbati ó ba de Ọrun Apadi ni ai si eto rara fun ohunkohun. Gbogbo ibẹ ri ṣúkuṣùku ṣùkùṣukù, ko si ọna kan ti ó gún gbogbo ọna ri wọ́gọwọ̀gọ.

"Lẹhin nã, ati Eṣu ati awọn ọmọ ogun Eṣu, ko si eyiti inu rẹ̀ dun rara ninu wọn, ṣe ni gbogbo wọn fajuro.

"Eṣu ko ri awa, ṣugbọn awa ri i dãdã. Nigbati Adeforiti yọ si i ni ãfin rẹ̀, ṣe ni Eṣu ta gìrì bi ó si ti nmu u kiri ọkan rẹ̀ ko balẹ rara, bi igi kan ba dá, aiya Eṣu a ja, bi ẹnikan fi ẹsẹ kọ, aiya Eṣu a là gàrà, ọkan rẹ̀ kò balẹ rara, hilahilo ni Eṣu nba kiri. Eleyi han gbangba bẹ̃ lara awọn iranṣẹ rẹ̀ pẹlu, tobẹ̃ ti Adeforiti fi bi Eṣu wò idi rẹ̀ ti ọkan gbogbo wọn ko fi balẹ bẹ̃. Eṣu dahun Eṣu wipe: 'Awa ti o jẹ pe iṣẹ ibi ni iṣẹ wa mọ pe ẹsan nbọ lọjọ kan, ṣugbọn a kò mọ wakati nã ti ẹsan o de.'

"A ba Eṣu lori itẹ. Ẹda ti o ba ni lẹru gbã ni, o ni iwo kan ṣoṣo lori, ina si njo lara iwo nã bẹ̃ni iwo pãpã ko jona, ó nị ìyẹ́ meji kùọ̀kùọ̀ kan bayi ni apa, ẽkan rẹ̀ si gùn, o dabi ẽkan awodi, ehin ẹnu rẹ̀ pupá o kun fun ẹjẹ, ẹjẹ l'o wà lẹnu rẹ̀ ti o duro fun bi itọ́ ẹnu, ehin wọnni gbõro ọkõkan to ehin mẹta papọ ṣe ọkanṣoṣo gbogbo ehin nã si mú bérébéré bi abẹ ìfárí.



Nwọn ko nmọ pe ejo ọka nį awọn ti ọwọ bọ̀ lẹnu.

Ẹsẹ Eṣu dabi ẹsẹ ògòngò, sibẹ o ṣe bi ọba, nitori ẹ̀wù ti o wọ̀ sọrun, ti gõlu ni, ṣugbọn gõlu nã ti dipẹta ẽri dudu dudu gbogbo ti bo o, ko dan bi golu mọ bẹ̃ni gõlu ni.

"Igbati Adeforiti ba a sọrọ nipa lébìrà ti ó ba lọ fun u tan, Eṣu ṣe ileri ati fun u ni lebira ṣugbọn o wi fun Adeforiti pe on fẹ fi diẹ han a ni Ọrun Apadi ki ó to lọ.

"Eṣu dide, Adeforiti nã tẹle e, awa nã tẹle wọn. Igbati a rin diẹ ni Eṣu wipe : 'Adeforiti, ibiti mo fẹ kọ mu ọ lọ ni ibiti a npe ni "Pakute Eṣu" ibẹ wà lati mã ran mi leti ati ṣe ibi ki nmá ba gbagbe.'

"Igbatį a de Pakute Eṣu yi nkan ti o kọ fi han a ni owo gõlu ti o pọ̀ ti o pupa ḍẹ̀dẹ̀ ti ò ndan yinrinyinrin. Nwọn kó owo nã sinu ibikan bayi ti o dabi ile ti enia kàn fun ẹiyẹ. Ṣugbọn lẹhin owo nã ni a ri ejo ọká ti ó ká jọ ti o gbe ẹnu soke ha-nha. Eṣu tọka si i, o wipe, 'Igbati mo ba wa si aiye ti mo ti ọmọ enia mu owo olowo, owo ti ki iṣe tiwọn, nwọn ko nmọ pe ejo ọka





ni awọn ti ọwọ bọ̀ lẹnu'. Lẹhin eyi, o tun fi ile kan han Adeforiti, a ri obinrin ati ọkunrin kan ninu ile nã a si ri ọmọ owú kan ni ilẹ. Igbati Eṣu de ibẹ o ni, 'Ẹ bẹrẹ kẹ̀' bi ó ti wi bayi, ṣe ni ọkunrin ki ọmọ owu mọlẹ ti o bẹrẹsi fọ ọ mọ obinrin lori, lẹhin eyi, Eṣu ni, 'Wo o bi ọkunrin nã ti nfọ irin mọ obinrin lori, bẹ̃ni tọkọtaya ni wọn'. A tun kuro ni ibi eyi o di ile miran, igbati a de ọhun, a ri awọn ọkunrin meji lori àkàsọ̀ kan, nigbati Eṣu de ibẹ o wi fun eyiti o wà ni isalẹ akasọ ki o fa ẹsẹ eyiti o wà ni oke, lõtọ eyiti o wà ni isàlẹ ṣe bi o ti wi, o fa a lulẹ werewere, o gba ipo rẹ̀. Bi ó ti joko si ipo onitọhun tan afi riri ti a ri ejo nla kan ti o nyọ ori bọ̀, ti o lọ mọ ọkunrin yi, were ó pa a were o gbe e mì. Bi o ti gbe e mì tan ni Eṣu dahun o ni, 'Ó fi èrú gba ibukun, ko duro gbadun ibukun'. A ba tun nlọ. Ko pẹ pupọ, a de ile miran a ri obinrin arẹwa kan ti ọ dara pupọ a si ri ọkunrin kan ti o duro ti i, bi a ti de ibẹ Eṣu wi fun obinrin nã, o ni, 'Ṣiṣẹ rẹ ki nri ọ'. Bi o ti wi bayi, ṣe l'a ri obinrin nã ti o rẹrin si ọkunrin ti o duro, o ni, 'Ko si ọkunrin miran laiye ti ó dara to ọ, ko si si ẹniti mo fẹran to ọ lode aiye titi de ara iya ati baba mi, fi ẹnu kò mi lẹnu, olufẹ mi ọwọn julọ'. Bi o ti wi bayi ti ọkunrin yi fi ẹnu ko o lẹnu ko jẹki ọkunrin nã gbe ori kuro lẹnu mọ, ó dì mọ ọ, o nfa a lọ o si fa a de ibi odò jijin kan o fa a ju sinu odo, odò gbe onitọhun lọ. Eṣu tun sọrọ o ni, 'Ko mọ pe ifẹ oju l'o ni si on, o fi ara silẹ o jẹki o fa on sinu odò'. Igbati a tun de ibikan a ri awọn ọkunrin mẹrin, igbati Eṣu de ibẹ o ni, 'Ẹ ṣe bi ẹ ti iṣe'; bi o ti wi bayi ni awọn mẹta mu ẹni kẹrin ti nwọn ko ọwọ rẹ̀ sẹhin ti nwọn fun u l'okun danindanin. Lẹhin nã nwọn ko ohun ini rẹ̀. Igbati nwọn tun ronu titi nwọn kuku pa a. Ko pẹ ti nwọn pa a tan ti awọn ẹnikan de ti nwọn mu wọn lọ. Ko si pẹ ti a ri i ti nwọn yẹgi mọ awọn mẹtẹta. O pẹ diẹ ni a tun ri awọn mẹta yi ti awọn jade nibomiran lati inu iyãra kan o si ya ni lẹnu pe ẹniti o ti ku tun dide, ṣugbọn afi igbati a ri i ti ẹnikan tun mu wọn ti o sọ wọn sinu epo gbigbona. Lẹhin eyi, Eṣu wipe : 'Wo o, awọn ọlọṣa ji owo olowo nwọn yẹgi mọ wọn ninu aiye, igbati nwọn tun de ọdọ mi l'ọrun mo sọ wọn sinu epo gbigbona'. Eṣu ba rẹrin diẹ bayi, eyi si ni igba kini ti a ri ohun ti o jọ ẹrin lẹnu rẹ̀.

"Ọpọlọpọ nkan ni a tun ri ni Pakute Eṣu ni Ọrun Apadi, ṣugbọn ko si aye lati to gbogbo wọn lẹṣẹṣẹ.

"Eṣu tun mu Adeforiti lọ si ibiti ó pè ni Òpópó Ìyà-ẹ̀ṣẹ̀. Ibi yi ni nwọn ti nfi iya jẹ gbogbo ẹniti o ti ṣe ibi ninu aiye ki nwọn to fi aiye silẹ ṣugbọn eyiti o buru julọ ni pe nwọn ko tun le ku mọ, ki nwọn mã jiya titi ṣa ni. Ẹniti a kọ ri ya ni lẹnu pupọ, iranṣẹ Eṣu kan l'o joko ti ọkunrin nã ti ó ngba ìṣó mọ ọ loju ti onitọhun nke ṣa. Ẹnu ya Adeforiti pupọ ṣugbọn Eṣu wi fun u ki ó má jẹki ẹnu ya on ki ó má si ṣe kãnu rẹ̀, Eṣu ni, 'O kò mọ bi ọmọ araiye ti le to ni, ẹniti iwọ nwò yi ti yọ oju ẹni mẹfa lode aiye, ó ti paṣẹ ki nwọn yọ ẽkan ọmọ ika ẹsẹ mẹwẹwa ẹni mẹfa lãye laijẹ pe nwọn ti ku, ko ha yẹ ki on nã jiya diẹ ni?' A tun ri ẹnikan ti o wà ninu ikoko irin, ikoko nã gbona tobẹ̃ ti o jẹ pe gbogbo ara rẹ̀ po l'o pupa dẹ̀dẹ̀, gbogbo ara ọkunrin nã bó bòròkòtò o nke, 'Ara nta mi o, ara nta mi o, ara nta mi o'. Ãnu rẹ̀ ṣe ni ṣugbọn Eṣu ko tilẹ sọ pe on gbọ nkan ti o nsọ, o wi fun Adeforiti pe ẹniti o ri yi ti ran awọ ẹranko mọ enia lara lode aiye ó si ti fa ẹni nã fun kiniun pa jẹ, ó ti gbe enia sinu posi lãye, o si ti ni ki nwọn kan posi pa, ó gbe onitọhan sinu posi lai jẹ pe ó ti ku. Nwọn so okùn mọ ẹnikan lapa ati lẹsẹ awọn iranṣẹ Eṣu meji fà a, nwọn nfi i ra ina ileru ti o tobi ti o njo ti o gba gbogbo agbegbe ibẹ lọ, ọkunrin yi nke ṣugbọn nwọn ko fisilẹ bẹ̃ni kò ku. Awọn miran wà ti nwọn ti fa apa wọn kan ya kuro lara ti nwọn ngbe kukute ti ó kù kiri ti ẹjẹ wà bálabàla loju apa ti nwọn faiya lọ ti oju egbò ko san ti ẹjẹ ko dawọ duro ti nwọn nrin bẹ̃ kiri. Ṣugbọn ki iṣe gbogbo awọn ara Ọrun Apadi l'o njẹ iru oró ti a sọ wọnyi, awọn ti nwọn njẹ iru iya buruku bawọnni ni awọn ti nwọn ti jẹ alagbara ni igba aiye wọn ti nwọn si ti lo agbara wọn lati fi da ọmọ ẹlọmiran l'oró iru eyiti a ti darukọ gbogbo. A de ibikan ti a ba ọkunrin kan ti o rọra joko ni on nikan ti o nsọkun ti ẹnikẹni ko si ni agbegbe ibiti ọkunrin nã wà rara, igbati Eṣu si fi i han Adeforiti o ni, 'Olowo patapata ni eleyi nigbati ó wà ni aiye, ṣugbọn ko fi owo rẹ̀ ṣe ẹnikẹni lõre, o le gbogbo enia kuro lọdọ rẹ̀, ki ifẹ ki ẹnikẹni sunmọ on. Nisisiyi, o ti ku, o wa si ọdọ mi, ó nwa ki on tilẹ ba ẹnikan sọ gbolohun





ọ̀rọ̀ kan ṣugbọn kò ri, o di ẹ̃dẹgbẹta ọdun ti ó ti de ibiti ó wà yi lai sọrọ si ẹnikẹni.'

"Onirũru ẹda ni o njiya ni Ọrun Apadi, a ri baba ti o yinbọn pa ọmọ rẹ̀ laiye, iya ti o fun ọmọ ni õgun jẹ lati fi pa ọmọ, aburo ti o lu ẹgbọn pa ati ọkẹ aimoye iwa buruku gbogbo ti awọn ọmọ enia nhu. Ẹṣẹ pọ laiye, a! Ẹniti o ba fẹ mọ bi ọmọ enia ti buru to ki oluwarẹ̀ lọ si Ọrun Apadi nitori ẹṣẹ ti ẹnikẹni ko le fi ẹnu rẹ̀ sọ, tabi ki ọwọ kọwọ kọ silẹ fun ati kà wà ninu ẹṣẹ ọmọ enia. Ṣugbọn inu Eṣu pãpã ki idun lati ṣe ibi ko si nle ṣe ibi lai jẹ pe ọmọ enia fun u ni aye. On pãpã wi fun Adeforiti o ni, 'A, Adeforiti, inu mi ko le dun lailai, nitori emi pãpã nfẹ fi ibi ṣiṣe silẹ nko le fi i silẹ ni. Ibẹrẹ ni nko ti tete ko ara mi ni ijanu ṣe ni mo bẹrẹ ni ibi kekere ṣugbọn diẹdiẹ ni iwa buruku mi nbi si i tobẹ̃ ti o jẹ pe, loni yi, ti ó ti to ẹgbẹgbẹrun ọdun sẹhin ti mo ti nhuwa ibi wọnyi, ó ti di aṣa mi gãn o ti di onjẹ fun mi, emi pãpã mọ pe iwa ti mo nhu ko le ṣe mi ni anfani, ṣugbọn ati fi iwa wọnyi siiẹ ko ṣẽ ṣe. Ṣugbọn, sibẹsibẹ, ki iṣe igba gbogbo ni mo nri aye lãrin awọn ọmọ enia, nitori bi ọmọ araiye ko ba ti fi aye silẹ, bi o ti wù ti mo sa ipa to nko nle ri aye lãrin wọn. Mo ranti ni aipẹ yi ti mo nti ọkunrin kan ki ija bẹ silẹ larin on ati aya rẹ̀, ṣugbọn iwa alakọri obinrin yi tutu ju fun mi, bi ọkọ ba ti nsọrọ lile ni on nsọrọ rirọ̀, bi ọkọ ti nfajuro ni on nrẹrin, igbati o ṣe, ọkọ pãpã le mi kuro lọdọ ara rẹ̀, mo ba tun ba irinkiri mi lọ.'

"Igbati Eṣu pari ọrọ yi, Adeforiti ri i pe akoko ti lọ, o wi fun Eṣu ki ó mu on lọ si ọdọ awọn lebira ti on nfẹ nitori on fẹ tete pada.

"Eṣu nã ba mu u lọ, ṣugbọn iyalẹnu l'o jẹ fun wa nigbati a de ibẹ ti o jẹ pe awọn ẹranko ni a ba, kiniun, agbọnrin, ẹkùn, ikõko, ẹfọ̀n, erin, malũ, rakunmi, ẹṣin, aguntan, ewurẹ, kẹtẹkẹtẹ, aja, ologbo, ekute, okete, ati awọn bẹ̃ bẹ̃ lọ. Ṣugbọn igbati Eṣu de ibẹ ti o na ọwọ soke bayi, ti o ni ki mejila ninu wọn jade, ṣe ni a ri ti awọn ẹranko wọnyi yipada ti nwọn di enia. O fi mejila ninu wọn fun Adeforiti, o tun rẹrin kekere bayi o ni, 'Emi ni mo sọ wọn di ẹranko, mo ti mu wọn kuro ni ipo enia, nwọn ko gbọdọ kuro ni ibiti o ti ri wọn yi, mo nlò wọn fun iṣẹ ṣiṣe ni'. Lẹhin eyi, o ni, 'Ẹ pada si ipo yin'. Were ni

gbogbo awọn enia wọnyi tun ti yipada ti nwọn di ẹranko afi awọn mejilã ti o fi fun Adeforiti ni Adeforiti mu wa si ile rẹ̀.

"Bayi ni a ri bi Ọrun Apadi ti ri. Ibi buruku ni. Pẹlu ayọ ni awa nã fi pada bọ, nitori ṣe ni gbogbo ibẹ nrùn ṣũ, ko si nkankan ti enia ri ti o ba ni loju mu, ko si orin kikọ, ko si ẹrin ririn, ko si ki ẹnikan ba ekeji ṣire, ibanujẹ kun ibẹ de ẹnu.

"Bi a ti pada de Àjùlé Ọrun ti a ṣi fila airi ori wa, ti iya Adeforiti wa ti Adeforiti njiṣẹ fun u, ni ọkunrin arẹwa alaṣọ funfun kan wọle, àṣé iranṣẹ Olodumare ni, bi o ti wọle ni a ri i ti ó ba Adeforiti sọrọ ni edè kan ti awa kò gbọ, afi igbati ó si mã jade ti o ju ọwọ si apakan bayi ti a dede wo ibiti o ju ọwọ si ti a ri ogunlọgọ ohun elo iṣẹ. Igbati o lọ tan ni Adeforiti sọ fun wa ti o wipe iranṣẹ Olodumare ni ati pe ṣe ni Ọba Ọrun ranṣẹ wa sọ fun on pe on ko gbọdọ jẹki awọn lebira ti on mu ti Ọrun Apadi wọnni de ibi ile Igbega-ọrun rara nitori iranṣẹ Eṣu ko gbọdọ de sakani Ọlọrun Ọba. O tun wi pẹlu pe gbogbo awọn ohun elo ti a ri wọnni, Ẹlẹda pãpã l'o fi wọn ranṣẹ, awọn ni idà iṣẹgun, ãke iṣẹgun, ọkọ́ iṣẹgun, akengbe iṣẹgun. O wi pẹlu pe nisisiyi ti on ti ri ohun elo wọnni a kò ni ba on ṣiṣẹ nã mọ, ki a ba on lọ sibẹ ni ọjọ keji ki a wa lọ woran.

"Igbati ilẹ ọjọ keji mọ, a lọ o di ibẹ. Bi Adeforiti ba si ti mu ada yi ti o fi ge eweko kan, ṣe ni ada a sa jade lọwọ rẹ̀ ti ada a mã tikararẹ̀ ṣiṣẹ lọ, bẽ nã ni ãke, bẽ ni ọkọ, bẽ ni akengbe, ki a má sa fa ọrọ nã gun lọ titi wakati kan ni ile nã gba Adeforiti ti o ba òke ọrun lọ. Ile yi ga ti nko ri iru rẹ̀ ri, o lẹwa rekọja ãla ko si si ẹniti o le ka iye iyãra inu rẹ̀ tan.

"Lẹhin eyi, a pada ba ile Adeforiti lọ Ṣugbọn mo fẹ sọ fun yin pe igbati mo nsọrọ 'ọjọ keji' 'ọjọ kan' ati bẽ bẽ lọ awa ti a jẹ ọdẹ ni a nka a bẽ, igbati o bá pẹ titi ti orun ba kun ni ti a si tun ji ni awa npe ni ọjọ keji, ṣugbọn Adeforiti ati iya rẹ̀ kò nsùn rara, ilẹ ki isi iṣu ni ibẹ pe ki enia dede ri okunkun, ṣe ni gbogbo ile nmọlẹ titi ọjọ aiye lãrọ lalẹ l'ọganjọ oru.

"Igbati o to bi ọsẹ kan ti a ti de ibẹ mo wi fun iwin ọrẹ wa yi pe a fẹ mã lọ si irinajo wa. Igbati o si ti ki wa dãdã ti iya rẹ̀ nã ti sure fun wa tan ni o ṣi ilẹkun kan bayi fun wa. Jĩjade ti a jade, oju ọna Oke Ironu ni a jade si, ni ibiti a ti kọ ri i.



## WÈRÉDÌRAN TI NGBE ILE ÒMÙGỌ̀PARAPỌ̀

"A kọju si ọna wa, a nlọ, a ko si ri nkankan ju bẽ lọ titi o fi di owurọ ọjọ kan bayi, ni nkan bi agogo mẹwa, ti a ri ọna kan ti o yà ba apa ọtun lọ. A ri akọle yi, o tọka si ọna nã: 'Eleyi ni ilu awọn Alaṣeju nibiti Ọba Alaiyeluwa Aláṣetẹ ti nṣe ọba wọn.'

"Orukọ ilu yi ko fa ni mọra, ṣugbọn bi ko ti fa ni mọra to yi nã, a fẹ lati lọ mọ ibẹ, nitori a le lọ de ibẹ ki a ri ọgbọn diẹ kọ.

"Igbati ó kù diẹ ki a wọ ilu nã, a bẹrẹsi gbọ ariwo, igbati a si de ibẹ ariwo nã ti pọ tobẽ ti ati gbọ nkan ti ẹnikeji ẹni nsọ nsoro. Bi a ba mu ti ariwo yi kuro, ilu nã dara, nitori nwọn ni mọto, nwọn ni kẹ̀kẹ́, nwọn ni alupupu, ọpọlọpọ nkan ọ̀làjú ni nwọn ni. Ṣugbọn aṣeju wọn nipa eto ṣiṣe ti pọ ju, ilu ibẹ ni mo ti mọ pe ko si nkan nã ni ode aiye yi ti aṣeju rẹ̀ dara. Àṣé eto ṣiṣe tun le ni àṣejù ninu! Gbogbo ilu nã po, wakati kannã ni nwọn nlo lati jẹun, iṣẹju kannã ni nwọn nilati bu okele. Bi akoko onjẹ ba ti nto, nwọn o lu agogo, were ọlọpa a fọn ka inu ile. Ẹniti o ba fi iṣẹju kan ṣãju tabi iṣẹju kan pẹ ki o to bu okele, ẹ̀wọ̀n ni. Ẹnikẹni ko gbọdọ sọkun lai jẹ pe o to akoko ẹkun. Akoko ti awa si de ibẹ, akoko ẹkun ni. Bi ẹkun gbọn ni, bi ko gbọn ni, dandan ni ki oluwarẹ̀ ke hĩ! hĩ! hĩ! ni akoko ẹkun ni ilu awọn Alaṣeju. Akoko ẹ̀rín wà lọtọ pẹlu, bẽ ṣa ni gbogbo eto wọn.

"Nigbati akoko ẹkun kọja tan ti mo wọ ile ti nwọn ti nta nkan bayi, ọkunrin kan wọle, o ko ọpọlọpọ owo lọwọ. Fila kan ni o fẹ ra o, ṣugbọn bi o ti de ibiti nwọn ti nta ọja ti o ri awọn arẹwa wunndia ti nwọn nta ọja-nã, ti nwọn nmì, ti nwọn nyan niwaju rẹ̀, ti nwọn npọn on nã, ti nwọn nfi ọja gbogbo han a, o bẹrẹsi nawo o ra gbogbo nkan ti ko ni ero ati rà tẹlẹ, o na gbogbo owo tan, bẽni apo owo meji l'o gbe wa.

"Mo ba bi ọkunrin kan bayi ki o sọ fun mi orukọ ọkunrin ti o na iru owo yi, ẹniti mo bi lẽre wi fun mi pe on ni Ọgbẹni Weredìran ti ngbe Ile Omugọparapọ.

"Ko pẹ pupọ ti Werediran wa si apa ibiti mo wà ti o sọrọ si mi, a ba ara wa sọrọ dãdã, emi pãpã si tilẹ nfẹ lati ba a ṣe ọrẹ ki nba ri aye fun u ni imọran diẹ, nitori bi o ti ṣe nawo yi ko tẹ mi lọrùn rara. Ki a má sa fa a gun lọ titi, ó bẽre ibiti mo de si, mo sọ fun u, o si sọ ibiti on nã ngbe fun mi, o wi fun mi pe on nbọ wa bẹ̀ mi wo ni ọjọ keji.

"Nigbati mo kuro ninu ile ti mo ti lọ ra nkan yi, emi ati awọn ẹnikeji mi yi ilu nã lọ. Igbati o mã to agogo mẹta a pada si ile ti a wọ̀ si. Werediran ọrẹ mi ti wi fun mi pe ki nmaṣai jade ni agogo marun wa woran nitori akoko nã ni akoko ijo.

"Nigbati o di agogo marun lõtọ, gbogbo ilu bẹrẹsi jo a si ngbọ ìlù lọtun losi. Ko pẹ pupọ ti a ri Werediran ti o njo bọ. Ìlù bàtá l'o njo, nwọn bẹrẹsi lu ilu bayi, 'Werediran, o jẹ gọ-ngọ gbese, gbese, o jẹ gọ-ngọ ; nitori wunndia, o jẹ gọ-ngọ gbese, gbese, o jẹ gọ-ngọ ; nitori adelebọ, o jẹ gọ-ngọ gbese, gbese, o jẹ gọ-ngọ ; nitori afẹ aiye, o jẹ gọ-ngọ gbese, gbese, o jẹ gọ-ngọ ; nitori ainironu, o jẹ gọ-ngọ gbese, gbese, o jẹ gọ-ngọ ; nitori fãri, o jẹ gọ-ngọ gbese, gbese, o jẹ gọ-ngọ ; o ku b'o ti mã ṣe e, o jẹ gọ-ngọ gbese, gbese, o jẹ gọ-ngọ, etc.'

"Bayi ni nwọn nlu ilu nã, eyiti o si tilẹ ya ni lẹnu ni bi Werediran ti njo ijo ìyà nã tayọtayọ, nitori igbati awọn onilu ba fi ilu wipe 'Werediran' on a dahun a ni 'O jẹ gọ-ngọ gbese, gbese, o jẹ gọ-ngọ'.

"Igbati o tilẹ ṣe o ni ki awọn onilu mã ki on awọn ba bẹrẹ nwọn ni, 'Werediran, Werediran, Werediran, ti ngbe Ile Omugọparapọ, Omugọparapọ, Omugọparapọ, bi o ba buru tan, iwọ nikan ni o kù, iwọ nikan ni o kù, iwọ nikan ni o ku, Werediran, Werediran, Werediran, ọwọ epo ni araiye nba ni ila, ọwọ epo ni araiye nba ni ila, ọwọ epo ni araiye nba ni ila, nwọn kò nba ni la 'wọ ẹjẹ, nwọn ko nba ni la 'wọ ẹjẹ, nwọn kò nba ni la 'wọ ẹjẹ rá rá rá rá rá' (ilu tun sọ).

"Igbati o di ọjọ keji, Werediran wa bẹ̀ mi wo gẹgẹ bi o ti sọ, emi nã si wi fun u pe ng o de ile rẹ̀ lọjọ kẹta eyini.

"Igbati o di ọjọ kẹta mo mura o di Ile Omugọparapọ lati lọ ki Werediran O dun mi lati ri i pe ki nto de ibẹ agogo ẹkun sisùn ti lu, gbogbo ilu si ti bẹrẹsi sọkun, ṣugbọn nigbati mo de





Ile Omugọparapọ ni mo ri i pe ẹkun gãn ni awọn nsun. Nkan ti o npa wọn lẹkun ni yi :

"Ile kan wa ni eti ile Omugọparapọ orukọ ile nã a mã jẹ Wọbiaparapọ. Ọrẹ ìmùlẹ̀ patapata ni awọn ara Ile Omugọparapọ ati ti Wọbiaparapọ jẹ, ọrẹ nã jinlẹ gidigidi. Gbogbo awọn ara Ile Omugọparapọ ni o ni iyawo, ṣugbọn àpọ́n ni awọn ara ile Wọbiaparapọ, ẹnikan ko ni iyawo ninu wọn. Ibanujẹ nla l'o si jẹ fun awọn ara ile Omugọparapọ pe bi ò tilẹ jẹ pe gbogbo wọn ni o ni iyawo sibẹsibẹ iyawo wọn kan ṣoṣo ko bimọ. O wa ṣe, ni awọn ara ile Wọbiaparapọ wi fun awọn ọrẹ wọn ti iyawo wọn ko bimọ yi pe ki nwọn jẹki awọn iyawo wọnni wa gbe ile awọn ni odidi ọdun kan ki awọn ba wọn wa egbõgi ti o daju fun aibimọ wọn wọnyi, nitori, ṣe ki a sọ õtọ kọ? Olõgun ni gbogbo ara ile Wọbiaparapọ jẹ, nwọn ko si ni ero buburu kan lọkan rara nigbati nwọn wi bẹ̃. Ṣugbọn, ṣe gbogbo enia ni o mã ngbadura ki on maṣe bọ sinu idanwo! Ẹniti o gbe idanwo nla ka ọrẹ ìmùlẹ̀ laiya ni o wipe ki onitọhun ṣe àbòsí si on.

"Lõtọ awọn ara ile Wọbiaparapọ kó gbogbo òbinrin ile Omugọparapọ lọ si ile wọn, o si di ọdun kan gbako ti eyi ti ṣẹlẹ gãn ni emi lọ ki Werediran. Ọjọ keji ti awọn ara ile Omugọparapọ ti nreti iyawo wọn ni mo de ibẹ. Owurọ ọjọ ti mo si de ibẹ yi ni awọn iyawo ranṣẹ si wọn pe awọn kò wa mọ nitoripe awọn ti ni ọkọ miran si ile Wọbiaparapọ.

"Iwe ni iyawo Werediran tilẹ kọ si i, nigbati o si fi iwe nã han mi nkan ti nwọn kọ sibẹ ni eyi :

"'Ile Wọbiaparapọ
"'Ilu Alaṣeju
"'Ọjọ kẹtalã, oṣu kẹjọ
"'Ni Ẹdẹgbẹwa ọdun o
"'le mejileladọta lẹhin
"'Iku Oluwa wa.

"'Si,
"'Ọgbẹni Werediran
"'Ile Omugọparapọ
"'Werediran mi ọwọn,
"'Bi emi ati bãle mi ti fi ẹdọ ẹran jẹun tan ni owurọ yi, ti iṣãsun ọbẹ yi mi ka, ti ikoko elubọ fẹhinti ni yãra,

Nelson books give sound education 978 126 238 7

ÀDÌÌTÚ OLÓDÙMARÈ

D.O. FÁGÚNWÀ

# ÀDÌÌTÚ OLÓDÙMARÈ



D.O. FÁGÚNWÀ

# ADÌÌTÚ OLÓDÙMARÈ



'Kiniun rẹ mu u lo si ibikan bayi, igbati o de ibẹ ehin erin ti o ba ju ẹgbaji lọ' (Oju iwe 39).

# ÀDÌÌTÚ OLÓDÙMARÈ

## PẸLU ỌPỌLỌPỌ IBERE

Lati ọwọ

D. O. FAGUNWA, M.B.E.

Ẹniti o kọ iwe

*Ogboju Ọdẹ Ninu Igbo Irunmọlẹ, Ireke Onibudo,*

ati bẹ̃ bẹ̃ lọ

*Ẹniti o ya awọn aworan inu iwe yi ni*

*E. I Adenuga*

Nelson Publishers Limited

Published by
Nelson Publishers Limited

*in assocation with*

Evans Brothers (Nigeria Publishers) Limited,
Jericho Road, PMB 5164, Ibadan, Nigeria.

Tel: 02-2414287, 2414394, 2413708

E-mail: evans@skannet.com
evans@evanspublishers.com.ng
Web: www.evanspublishers.com.ng

© Nelson Publishers Limited 2005

First published 1961
Reprinted 1962, 1963, 1964, 1966, 1967, 1970, 1971, 1973, 1975, 1976, 1979, 2005, 2007, 2008, 2011

All rights reserved. No part of this publication may be reproduced, stored in a retrieval system, or transmitted in any form or by any means, electronic, mechanical, photocopying, recording or otherwise, without the prior permission of Nelson Publishers Limited.

ISBN 978 126 239 7

Printed by NERVES Molete, Ibadan.

## DEDICATION

*Dedicated, by permission, to*
*Chief the Honourable Obafemi Awolọwọ,*
*the first Premier of the Western Region*
*of Nigeria.*

## FIFIJUBA

**Mo fi iwe yi juba Oloye Ọbafẹmi Awọlọwọ**
**Ẹniti o jẹ Olotu Ipinlẹ Iwọ Ōrun Nigeria**
**kini, mo si ti gba aṣẹ lọwọ rẹ̀ lati ṣe eyi.**

# Ọ̀RỌ̀ AKỌSỌ

Iwe yi wa fun tọmọde tagba lọkunrin lobinrin ti nwọn mọ ede Yoruba ka dãdã. O wa fun-lilo pẹlu awọn iwe mi miran ti awọn ọmọ ile iwe nka ninu ile iwe wọn, iwe bi "Ogboju Ọdẹ", "Ireke Onibudo" ati bẹ̃ bẹ̃ lọ. Bi awọn ọmọ ba ka eyikeyi ninu awọn iwe wọnyi bi o ti yẹ, dandan ni ki nwọn lo meji pọ ni ọdun kan, ki nwọn pari ọkan ni oṣu mẹfa iṣãju, ki nwọn pari ekeji ni oṣu mẹfa ti o tẹle e.

Mo ni ọrọ pataki lati sọ nipa iwe yi fun awọn ti nwọn nkọ Yoruba pataki fun idanwo ṣiṣe. Idanwo bi iru eyiti awọn olukọ nṣe ni ile ẹkọ giga ti a ti nkọ wọn (Grades II and III Teachers Examination) tabi fun idanwo àbájáde ile ẹkọ Giramọ (West African School Certificate Examination). Yio jẹ iranlọwọ bi nwọn ba ka iwe yi dãdã tobẹ̃ ti awọn gbolohun ọrọ ninu rẹ̀ yio kó wọ wọn ninu agbari lọ, iwọnyi ni nwọn le lo ti yio ran wọn lọwọ nigbati nwọn ba ndahun ibẽre ni igba idanwo.

Nkan kan ti o tun ṣe pataki fun awọn ti nṣe idanwo ni kíkọ́ ilo awọn àmì ori ọrọ Yoruba, eyini ni àmì ti a fi nmọ bi o ba yẹ ki a rẹ ohun silẹ nibikan tabi ki a gbe e soke.

Ami wọnyi ko ju bi oriṣi mẹta lọ, ṣugbọn, sibẹ, bi o ti kere to yi, ṣaṣa awọn ti nka Yoruba ni nwọn nmọ wọn ki o daju ṣakaṣaka. Ki olukuluku ṣe akiyesi awọn àmì wọnyi bi nwọn ti yọ lori oriṣiriṣi ọrọ ti a lo ninu iwe yi nitori ati ba le gbadun Yoruba nã dãdã ati nitori idanwo wọn.

Ẹ o ri i pe mo fi iwe nã juba Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ẹniti o jẹ Olotu kini ni Ipinlẹ Iwọ Õrun Nigeria yi. Idi rẹ̀ ni eyi, mo ti ronu jinlẹ gidigidi, mo ti nwo Oloye nã ni oriṣi igba lái jẹ pe o mọ pe mo nwo on, mo ti wadi rẹ̀ to ibiti a nwa idi enia de, paripari nkan ti ọkan mi si sọ fun mi, ti ẹ̀rí ọkan mi tì lẹhin si ni pe bi a ba wipe igbesi aiye enia kan dara fun àwòkọ ti ọkunrin nã ni. Ó dara fun àwòkọ fun ẹnikẹni ni ori ilẹ aiye nibikibi ti enia le wa, ni orilẹ ede k'orilẹ ede ti o

si le jẹ. Bi o ba jẹ pe awọn ara ọrun nri nkan ti awọn ara aiye nṣe, inu Oduduwa pãpã ko ni ṣai dun ni ode ọrun ti o ba wo ohun ti Oloye yi nṣe fun awọn ọmọ on, ti ki iṣe awọn ọmọ on nikan bi ko ṣe fun gbogbo ẹya enia dudu jakejado ilẹ wa yi porogodo nitori wipe, ni ki aṣãju sọrọ ki a ba ọrọ nã bẽ, ki olori jẹ olododo ki enia le gbẹkẹle e, ki aṣãju ko awọn enia ja-nkan-ja-nkan si abẹ, ki gbogbo wọn ti i lẹhin de ibi ki a má gbọ pẹ́rẹ́, ki a má gbọ pù, ki a má gbọ ija ki a má gbọ ìta. Ki Aṣãju wọ aṣọ ibilẹ ki o fi aṣọ ibilẹ wu ni, ki Aṣãju sọrọ, ki o dabi ẹni pe ki a mã pọn ọ ni ete la, ki Aṣãju jẹ́ akin nigbati ẹru nba ọmọ ẹlomiran ki Aṣãju fi Olodumare siwaju, ki o fi Olodumare sẹhin, ki o fi Olodumare si apa ọtun ki o fi Olodumare si apa osi, ṣaṣa enia ni a le fi we ọkunrin yi ni ode aiye.

Ẹ maṣe ṣì mi gbọ ṣe ni mo fẹ ki ẹ kọ ọgbọn lara eleyi.

Idi meji pataki ni mo fi sọ nkan ti mo sọ.

Idi ekini ni pe, emi yi ti gbe ọpọlọpọ ọdun ni ilẹ Gẹ̀si, mo si ti kuro ni ibẹ, mo ti rin lãrin Oyinbo miran, mo si ti ri i pe orilẹ ede k'orilẹ ede ti nwọn ba ni aṣãju ti o to aṣãju ṣe, pípọ́n ni nwọn mã npọn wọn fun gbogbo aiye loju aṣãju bẹ ki aṣãju bẹ to ku, ati lẹhin rẽ ni ẹgbẹgbẹrun ọdun fun iran ti nbọ lẹhin. Iru ẹni bẽ, fọ́rífọ́rí ni nwọn mã nfi wọn ṣe. Awa ọmọ Yoruba, ko si yẹ ki a fi tiwa pamọ, bi a ri olowo o yẹ ki a kigbe olowo wa, bi a ba ri ọmọwe o yẹ ki a fọn ipe iwe rẽ lori orule, bi a ba si ri àtàtà Ọ̀ṣẹ̀lú, o yẹ ki a polowo rẽ lori oke giga.

Idi keji ṣe pataki pupọ. On ni eyi, ki a to le sọrọ enia kan ní bi a ti sọrọ ti oloye yi, dandan ni ki oluwarẹ̀ ti bori ọpọlọpọ iṣoro.

Ẹnyin enia wa, ohun ti ẹnikan ba le ṣe ẹlomiran le ṣe e. Oloye Awolọwọ ti bori iṣoro tirẹ̀.

Ní ohunkohun ti o ba de ba ni, ẹ maṣe jẹki a foiya, bi on ba le bori iṣoro tirẹ̀ awa nã le bori tiwa. Ẹnyin ọmọwe, ẹ le ṣe idanwo ki ẹhin idanwo ṣai dara, iṣoro ni eyi, ẹ le bori rẽ dãdã. Ẹ le ka iwe ki ó má ye yin to, iṣoro ni eyi, bibori ni ; ohunkohun le de ti yio fẹ fa yin sẹhin, iṣoro ni eyi, bibori ni ;



ẹnyin oniṣowo ẹ maṣe foiya bi gbese tilẹ de. Ẹ fun ṣokoto le, bibori ni. Agbẹ le ni oko ki ohun ọgbin má mu ere wa, bibori ni. Ede àiyedè le wa lãrin ọrẹ ati ọrẹ, lãrin baba on ọmọ, lãrin ọkọ ati aya gbogbo iwọnyi, bi oloye Awolọwọ ba le bori iṣoro tirẹ̀, Ọlọrun ti o da a nã l'o da gbogbo wa, a o bori iṣoro tiwa.

Lẹhinnã, mo tun fẹ ki ẹnyin ọmọ Yoruba ma ṣọra bi ẹ ba ti nhuwa nitori ọpọlọpọ ni yio fi iwa yin ṣe idajọ orilẹ ede yin láì jẹ pe ẹ mọ nkankan. Gẹgẹ bi apẹrẹ, mo ti bẹrẹsi ṣe akiyesi iwa ti ọmọkunrin Oyinbo kan ni Bank West Africa ni Ibadan nhù láì jẹ pe o mọ nkankan, nwọn npe Oyinbo yi ni B. J. Clark. Ó mọ iṣẹ rẹ̀ de ibi gongo, o si nṣe e lojumejẽji. Bi ó ba sọrọ a sọrọ jẽ, bi ó ri ẹnikẹni a yẹ ẹ si, bi ó ti yẹ, ní ṣoki, ọmọluwabi ni. Iru ẹni bi eyi ko ni ṣai ri igbega ni ibi iṣẹ. Leri gbogbo rẹ̀, ó gbe orilẹ ede rẹ̀ ga bẽni ko mọ pe ẹnikẹni nwo on. Bayi ni orilẹ ede miran nã ṣe le mã ṣe idajọ ẹnikẹni ninu wa. B. J. Clark yi kò mọ̀ pe mo nkọ ohunkohun silẹ nipa on di bi mo ti nkọ iwe yi. Ẹ jẹki a fi ọrọ ti Ọgbẹni Clark yi ṣe arikọgbọn, ẹnyin enia wa.

Nko le pari iwe yi lai dupẹ lọwọ gbogbo yin, ẹnyin ọmọ Yoruba, mo dupẹ lọwọ yin fun gbigba ti ẹ ti gba awọn iwe mi atẹhinwa gbogbo. Mo dupẹ lọwọ ẹnyin olukọ, mo dupẹ lọwọ ẹnyin akẹkọ, mo si dupẹ lọwọ ẹnyin alabojuto ile iwe gbogbo. Mo dupẹ lọwọ yin ẹnyin ti ẹ ngbe ilẹ "Kãrọ o ò jĩre", nitori ẹnyin l'ẹ jẹki awọn iwe mi de origun mẹrẹrin ilẹ yi. Mo gbadura fun yin ki Ọlọrun jẹki aiye yẹ yin, ki ẹ ni ibalẹ ọkan, ki ó má jẹ ki iku pa yin lọjọ aipe, ki o má si jẹki aisan fi idi yin ra ilẹ, ẹniti ara rẹ̀ ko le yio ni ilera, eyiti oju npọn yio ba owo pade gbogbo ẹnyin ọmọ ile iwe ti ẹ si ti ṣe idanwo, ihin rere ni ẹ o gbọ, bi gbogbo wa si ti nba igbesi aiye wa lọ ki Olodumare jẹki a gbo ki a tọ, ki a tan orukọ ilẹ wa kálẹ̀ de origun mẹrẹrin aiye.

Ọpọlọpọ enia l'o wa ni ode aiye ti o jẹ pe Olodumare mã nlo fun iṣẹ rere, ọkan ninu awọn enia bẽ ni ọrẹ mi' ọgbẹni P. N. Harris ti o ṣe iranlọwọ pataki fun mi ni akoko ti mo nkọ iwe yi. Mo sọ eleyi jade nitori bi ko ba si Ọgbẹni Harris yi, iba jẹ iṣoro pupọ fun mi lati pari iwe yi. Ọkunrin nã ni Alakoso Bank West Africa lakoko yi, ọmọluwabi ni.

Nko si le ṣai dupẹ lọpọlọpọ lọwọ gbogbo awọn alakoso ibiti nwọn ti ntẹ iwe mi lakoko yi fun iranlọwọ gbogbo ti nwọn ma ngbiyanju lati ṣe fun mi nigbagbogbo ti nwọn mã nṣe bi ọmọ iya fun mi. Awọn yi ni nwọn wa ni ibi iṣẹ Thomas Nelson & Sons ni Ilu Ọba. Mo dupẹ lọpọlọpọ lọwọ wọn.

D. O. FAGUNWA.



## IFIHAN


| | |
|---|---|
| Àlàbápàdé Àdììtú-Olódùmarè .. .. .. .. | 1 |
| Òbìrí-Aiye ati Ìpọ́njúdìran .. .. .. | 5 |
| Àdììtú-Olódùmarè pade ijangbọn lọna: nkan ṣe .. | 14 |
| Àdììtú-Olódùmarè di ero inu igbo .. .. | 31 |
| Àdììtú-Olódùmarè la ala iyanu .. .. .. | 46 |
| Àdììtú nfẹ Iyun-ade .. .. .. .. .. | 57 |
| Ẹhin igbeyawo Àdììtú-Olódùmarè .. .. | 92 |
| Ọjọ keji ninu ile Mọgaji Ẹnudunjuyọ .. .. | 108 |
| Ọjọ kẹta ninu ile Mọgaji Ẹnudunjuyọ .. .. | 131 |
| Igbẹhin Àdììtú-Olódùmarè .. .. .. .. | 145 |
| Àmì ori ọrọ Yoruba .. .. .. .. .. | 149 |
| Apẹrẹ iru nkan ti o le ba pade ninu idanwo oniwe mẹwa | 156 |
| Akiyesi pataki fun akẹkọ .. .. .. .. | 162 |

# ÀLÀBÁPÀDÉ ÀDÌÌTÚ-OLÓDỤ̀MARÈ

Ẹnyin ọrẹ mi l'ọmọde, ati pãpã ẹnyin ọmọ ile iwe, ẹnyin ọrẹ mi àgbalagba, ẹnyin enia wa l'ọkunrin, ẹnyin enia wa l'obinrin, ẹnyin ara aiye ni dudu, ẹnyin ara aiye ni funfun, ẹnyin ara aiye, ẹ̀ bã ṣai dudu, ki ẹ ṣai funfun, akoko òjò ni ọrọ yi ṣẹlẹ o. A ! ojo nã pọ gidigidi, ni inu mọto ayọkẹlẹ ti a wa ni ọjọ nã, ṣe ni ojo yi nlu ilu le wa lori, ti o ndun winniwinni bi omele ilu dùndún. Igbati o ba ṣe, à gbọ gbùrùrùrùrù l'apa ọtun, igbati o ba ṣe, à gbọ gbùrùrùrùrù lapa osi bi o ṣe à gbọ gìrìrìrìrì ni ibi iwaju, bi ọ tun ṣe, à gbọ gìrìrìrìrì ni ibi ẹhin, ojo nã l'o nkù bẹ̃ kiri, gbogbo, oju ọrun dudu bi aro, gbogbo iwaju funfun ruru afi bi igbati Olodumare ṣe iyẹfun fadaka, ti o nda a silẹ lati oju ọrun, ẹrọ ti o wa lara digi iwaju mọto, ti o mã nnu omi, eleyini nu omi titi, omi su u, àgbàrá tobi kọja àgbàrá, omi rẹ̀ to tu ọkọ dãdã. Koto gbogbo oju ọna nkọ, bi mọto ja si tihin a ja si tọhun, gbogbo ẹsẹ mọto ri ṣẹ́kẹṣẹ̀kẹ, awọn ti o si nrin loju ọna pẹlu, omi ti di àtè si ara awọn wọnni, ó lẹ̀ mọ wọn lara típẹ́típẹ́. Omi odo gbogbo ti o ti tòrò kinkin ti di pupa, eweko alara mimọ ti di elẽri, awọn ẹja mõkun nwọn ba isalẹ inu ibu lọ, ẹranko nka ṣíóṣíó kiri ninu igbo, awọn ẹiyẹ joko gúlútú gúlútú kãkiri ninu itẹ wọn, àgbàrá le ọpọ ejo jade lati inu iho, ejo erè nṣe làgbà loju omi, ohun alãye kan ko le wipe on gbadun rara, afi ekolo ti o njẹ aiye ori rẹ̀ kiri.

Igbati ojo nã si pọ pupọ to bayi, dẹ́rẹ́bà kò ri ibi iwaju mọ, asẹhinwa asẹhinbọ, dẹ́rẹ́ba fa kọkọrọ yọ loju mọto, o gbe ẹsẹ le ibi idaduro ọkọ, ọkọ duro gbọnin, o di ki a mã wa wo oju ara wa.

Bi o si tilẹ jẹ pe a ti gbogbo ilẹkun mọ ara wa lori pinpin, ti ẹnikẹni ko gbin, ti enia ko sọrọ, sibẹ ọkunrin kan lu mọto le wa lori. O kan ilẹkun lẹ̃kini, o kan a lẹ̃keji, o tun kan a lẹ̃kẹta, a ba ṣilẹkun a wo ode.

Igbati a wo ode, a ri arẹwa ọkunrin kan, mo fẹrẹ má iti

iri ẹniti o lẹwa to bẹ̃ ri lati ọjọ ti mọ ti de inu aiye. Bi a ti wo ode ni ojo dawọduro diẹ, ki a si tilẹ to sọrọ si ọkunrin nã, ni dẹ́rẹ́bà wa ti fi ina si mọto, mọto nlọ. A ko rin ju ẹsẹ mejila ti mo fi ni ki dẹ́rẹ́bà da mọto duro ki a tilẹ gbọ nkan ti ọkunrin nã mã sọ.

Ọkunrin yi de, nitori ti a ju ọwọ si i ki o wa. Bi o ti de ti o wo mi, ẹrin l'o bu si, o ni, "Ọmọ Beyioku, ṣilẹkun ọkọ rẹ fun mi, a ran mi si ọ ni, ile rẹ ni mo nlọ".

Were, mo ṣilẹkun ọkọ fun u, nitori gẹgẹ bi mo ti sọ, ọkunrin nã l'ẹwa gidigidi. Riri ti mo ti ri i ni ọkan mi ti fa mọ ọ. Ó pupa o si ga, kò sanra ju bẹ̃ lọ, bi mo si ti wipe kò sanra yi nkọ, o to ọkunrin dãdã. Ori rẹ ko tobi lasan kidiri, ẹhin rẹ ko ṣe kòbìtà bi ti ijapa, ọrun rẹ ko gun kọja ibiti o yẹ, ko dabi ọrun ẹiyẹ ogongo, bẹ̃ni ko kuru rekọja, ko dabi ọrun ologini, gbogbo awọn ẹya ara ọkunrin nã ba ara wọn mu, tapatẹṣẹ gbã ni, àwọ̀ ara ọkunrin nã pãpã ko le koko loju bi àwọ̀ ara ẹlẹgungun, ṣe l'o tutu loju ti o dabi ara omidan, bi ko ṣe pe ko di irun ori rẹ ni, bi ko ṣe pe ko ro aṣọ mọra bi obinrin ni, bi ko ṣe pe ko fi nkan dudu pa ipenpeju bi alágbaja, ko tọ nkan le ẽkan ọwọ ki o tun tọ si ti ẹsẹ, ko gbe apamọwọ fi tọju ọwọ, bi ko si ṣe pe ko rin irin gbẹ̀rẹ̀ lẹsẹ, obinrin ni a ba pe ọkunrin nã. Ni ọjọ ti mo ti nri ehin ti o funfun, nko ri ehin ti o funfun bi ti ọkunrin nã ri, ni ọjọ ti mo ti nri ahọn, nko ri eyiti o pọn dẹ̀dẹ̀ bi ẹnipe onjẹ ko kan a ri bi tirẹ̀, ni ọjọ ti mo ti nri oju ti o mọlẹ gãra, nko ba iru ti ọkunrin yi pade ri, ki a si sọ pe enia sọrọ o fi ọrọ wu ẹnikeji sọ, enia rin l'ẹsẹ, o fi irin wu ẹlomiran rin, enia wọ aṣọ, o mu ki a mã wọ aṣọ nã kiri, tabi iho imu ẹni mọ, tabi apa ẹni ko gun lasan jawala, tabi ọmọ ika ọwọ ba ọwọ mu, ọmọ ika ẹsẹ ba ẹsẹ mu, ti ọkunrin nã yatọ lọpọlọpọ. Nitori nko ba iru ẹni bẹ̃ pade ri, nko ro pe iya mi kàn a ri, nko si ro pe baba mi ṣe alabapade ẹniti o jọ bẹ̃ ri ki o to lọ si ọrun alakeji. Ẹniti o ga tan ti o ni iwọn-tunwọnsi ẹsẹ, ti ko gun soke tan ki ẹsẹ dabi àgéré ni ilẹ—iru eleyi l'o wọle de, ti o ba mi loju ọna, ti o ni ki a mã gbe on kiri.

Ẹnyin ọrẹ mi, a ba mà gbe e o, igbati o si jẹ pe ile ni mo nlọ, ti on pãpã tun sọ pe ile mi ni on nlọ, a fi ori le ọna ile,





ṣugbọn bi ó ba yẹ̀ ni ọrọ bi meji ti a ti sọ si ara wa nigbati ó fẹ wọ inu ọkọ, ẹnikan ko sọrọ si ekeji mọ, ẹnikan ko gbin titi a fi de ile.

Ki a to de ile ni ara ti nfun mi ki ó má wa lọ jẹ pe iru awọn ti o ti mã nwa mi wa ile ti nwọn mã nsọ itan igbesi aiye wọn fun mi ni mo tun ba•pade. Lõtọ nã, bi mo ti de ile ti mo ki awọn ara ile tan ti mo joko si õdẹ ti on nã joko ni o ti pe mi ti o bi mi bi mo ba ni ohun ikọwe ninu ile mi, nitori on ni ọrọ lati sọ fun mi ti o le gun diẹ ti on o si fẹ ki nkọ silẹ fun awọn ọmọ araiye. Igbati o wi bayi, mo bẽre, mo ni, "Gigun to bawo?" On na rora rẹrin diẹ bayi o ni, "Gigun gbõrọ ni". Mo dahun mo tun ni, "Gbõrọ to bi bawo?" On nã si fesi o ni, "Yio gun to iwe kan gidigbi".

Ẹru wa ba mi wayi, mo ni, "Ki oluwarẹ mã sa fun ijangbọn, ki ijangbọn mã le oluwarẹ kiri, ki oluwarẹ wipe ọn ko le sọrọ, ki ọrọ sisọ mã le ni ka, ki enia wipe on ko kọwe mọ, ki iwe ni afi dandan bi o kọ on! Ọrọ mi mà di ọwọ rẹ o, Ọlọrun Ọba."

Bayi ni mo sọ, mo si ti gbagbe ara patapata, emi ṣebi mo nsọrọ sinu, àṣé gbangba ni mo nsọrọ ti gbogbo aiye ngbọ ohun ti mo nsọ. Igbati mo si gbe oju wo oke ti mo tun ri ọkunrin nã, oju ara mi ti mi, mo ba nfi ọrọ awada bo ọrọ ti o ti ẹnu mi jade mọlẹ ki o má ba dabi ẹni pe alejo mi ko jọ mi loju, pe mo nhuwa bi onigberaga, mo ni, "Ọrẹ mi, mã ba ọrọ lọ ọjare, inu ojo ti o pa wa lọna l'o tilẹ nbi mi ti ko jẹki nmọ ohun ti mo nsọ."

Ọkunrin nã wa da mi lohun wayi, o ni, "Njẹ o ranti àlá ti o la ni oru ọjọ kẹrindinlogun mọju ọjọ kẹtadilogun oṣu keje, ni ẽdẹgbẹwa ọdun o le mejidilọgọta lẹhin iku Oluwa wa?"

Ẹru wa ba mi na wayi, nitori õtọ ni mo la ala nlá kan ti o ba mi lẹru gidigidi, ẹnikan ṣoṣo ni mo si rọ ọ fun ni ode aiye, on nã ni ọrẹ mi kan, nko si ro pe ọrẹ mi yi rọ ọ fun ẹnikẹni, ṣugbọn mo kọ akọsilẹ àlá nã sinu iwe kekere kan.

Ṣe ni mo dede la ala ti mo ri baba mi ti o ti ku, ti o ti rekọja oke odo, ti o ti ki aiye pe o digbõṣe, ti o jade ninu ile nla kan. Ara rẹ ti yipada patapata, o dabi ara ọmọde. O ri mi, o pe mi bi iti ipe mi ni ode aiye o ni ki ntẹle on. A wọ inu ile nla miran lọ. Dídé ti a de ọhun ni mo bẹrẹsi ri pupọ ninu awọn

ara ile wa ti nwọn ti kọja lọ, mo ri ẹgbọn mi obinrin ti o ti ku ki baba pãpã to ku, mo ri awọn aburo mi ọkunrin ati obinrin ti nwọn ti fi aiye silẹ loju baba mi, mo ri ẹgbọn mi ọkunrin ti o jẹ ọmọ iya baba mi lode aiye, mo ri aburo iya mi ti o jẹ ọdẹ ti o ti ku, mo tun ri ẹgbọn mi ọkunrin ẹni pataki ninu iṣẹ oṣelu ati ijọ awọn onigbagbo, gbogbo wọn ni mo ri porogodo. Lẹhin ti mo ri wọn tan ni baba mi bẹrẹ ọrọ o ni:

"Ọmọ mi, ọmọ mi, ọmọ mi ọkan mi ko fi ọ silẹ lati ọjọ ti mo ti fi ọ si aiye lọ, mo si fẹ ki o mu ọrọ yi ti mo mã sọ ṣẹ nigbati o ba lò akoko. Maṣe gbagbe pe emi ti kuro ninu ibanujẹ ode aiye, mo ti bọ lọwọ rogbodiyan awọn ọmọ enia, mo ti kuro ninu ijamba ile ati ijamba ode.

Ninu awọn ẹmi ni emi wa yi, nibiti ẹnikẹni ko nṣiṣẹ ki o to jẹun, ko si pe a gbin ọgẹdẹ pe ọgẹdẹ ko so, ko si pe kòkó so, kòkó kò tà, tabi pe a ji ni owurọ, oju npọn ni. Ṣugbọn, ọmọ mi, aiye ni iwọ wa. Yio si pẹ si i ki o to wa ba mi. Oju ala ni mo ti nba ọ sọrọ yi. Wo ọkunrin ti o duro si apa ọtun rẹ, wo o, ki o tun u wo, wo o dãdã, nitori yio wa si ọdọ rẹ níjọ̀miran, lati sọ ohun ti gbogbo wa ti o wa nihin nfẹ ki o ṣe, enia ni on pãpã jẹ, on nã ko iti ifi ẹmi bora bi aṣọ, o digba diẹ ná, ọmọ mi, ọmọ mi, a, ọmọ mi, ki awọn aburo rẹ gbogbo fun mi."

Ọrọ bayi ni baba mi sọ fun mi loju ala, igbati mo si ranti gbogbo ala nã tan, ti mo tun ọkunrin nã wo, ni mo ranti pe ọkunrin yi ni baba mi fi han mi loju ala mi. Bayi ni ẽmọ nã ṣẹlẹ, ẹnikẹni ko pitan fun mi ri pe ẹni meji jọ la ala kannã pọ ri, bẽni emi ọkunrin yi jọ la a, nitori bi mo ti tun nrọ ala nã ni o ngbọn ori ṣẹ́ṣẹ́ pe on ranti gbogbo rẹ̀ lẹsẹlẹsẹ. On pãpã ti ri mi bi mo ti ri i. Igbati mo si dakẹ ti nko sọrọ mọ ni on nã ba bẹrẹ ọrọ tirẹ̀, o ni:

"Emi ni Àdììtú-Olodumare ti mbẹ ni ilu Ìlákọ̀sẹ. Baba mi ni Òbìrí-aiye, iya mi ni orukọ rẹ̀ si njẹ Ìpọ́njúdìran."

Ibiti mo le kọ ọ mọ ní ede tirẹ̀ ni eyi, ẹnu rẹ̀ yá pupọ, bi o ti nsọ ọkan ni o nsọ ekeji, bi o ti nsọ ekeji ni o nsọ ẹkẹta. Mo kuku ko gbogbo ohun elo ikọwe da silẹ mo ni ki ó mã sọ itan ara rẹ̀, ki ńmã fi eti gbọ ọ, igbati o ba sọ ọ tan ki emi wa kọ ọ ni ede ara temi. Bayi ni itan ọkunrin nã wa lọ:





Njẹ iwọ mọ ki enia talaka gãn? Ki enia talaka bi ẹnikẹni ti le talaka to, ki enia ji, ki kọbọ ṣe alái ba a ji, ki enia ko aṣọ si ara ki o dabi jọ̀wọ̀lọ̀ ọgẹdẹ fun akisa, ki odidi ilẹ ọjọ kan ṣu lái bu omi si ẹnu, ki enia talaka de ibi pe o nba adiẹ ṣa agbado ni ilẹ ki on ba fi agbado nã se ẹwa jẹ, ki enia di ẹniti o nti ẽpo iṣu ti a fi gun iyan jẹ, ki enia bọ si ori ãtan ki o mã wa ẽpo burẹdi, ki ẹlẹwa jẹ ẹwa tan ki a mã fi ẽkan ha idi ikoko ẹwa, ki o di pe olonjẹ nwa onjẹ a ti itori bẽ lọ le gongo sile olonjẹ, ki ọkunrin ní woro ibantẹ kan gẹgẹ bi aṣọ, ki obinrin má ni ju yẹ̀rì, ki enia talaka ki ó má ri owo fi ra kan-in-kan lasan wẹ̀, ki enia ri i, ki o ṣe bi were ni; ki gbogbo arã ile kọ ni silẹ, ki arã ode kọ ni silẹ, ki ọrẹ ìmùlẹ̀ ri ni ki o yara mã salọ, ki enia talaka ki o má ri abẹ́ òrùlé sun si, ki enia ji pẹlu ironu, ki o suṇ pẹlu ironu, ki o sọrọ pẹlu ikanra, ki o wà bi oku lãrin alãye ki Ọlọrun má fi iru ipọnju bayi ṣe tiwa.

Sibẹ, bayi ni awọn obi Àdììtú-Olodumare talaka to ni igba kan, idi ti nwọn fi talaka ti o to iru eyi, mo nilati sọ fun yin.

Ilu ti nwọn ngbe ni a npe ni Ìlákọ̀sẹ. Orukọ ilu yi le ya yin lẹnu, nitori orukọ rẹ̀ ba orukọ ẹranko kekere kan ti o dabi igbin mu. Ìlákọ̀sẹ ní igba lẹhin ti o dabi ti igbin. Bi igbin ti ifa kiri ni ìlákọ̀sẹ nfa kiri ṣugbọn bi ìlákọ̀sẹ gbe ẹgbẹrun ọdun laiye ko le to igbin lailai. Bi a ba si tilẹ wo igbin pãpã, ẹraṇ melo ni ó ní lara? Bi enia fi igbin kan se ọbẹ ko si bi o ti le tọ ọbẹ nã lò to ti o le gba ju ọjọ meji, o pẹ tan. Ni ilu Ìlákọ̀sẹ wayi, ko si ẹranko kan nibẹ ni ode aiye yi ti o ju ìlákọ̀sẹ lọ. Ẹnikẹni ko gburo ẹtu ninu igbo Ìlákọ̀sẹ ri, enia ko ṣe alabapade ẹ̀kìrì, ko si pe a nri oju ẹsẹ akata, ko si ti agbọnrin bẽni ko si ti imado. Ewurẹ ti kọ Ìlákọ̀sẹ silẹ, aguntan ti kọ ọ, ologbo kọ ọ, aja kọ ọ, pẹpẹiyẹ si kọ ọ pẹlu, afi bi ẹni pe Ẹlẹda pãpã ti pinnu lọkan rẹ̀ pe afi bi iya jẹ awọn ara Ìlákọ̀sẹ.

Ilu ti a nwi yi ko tobi rara, bọya ni ile ti o wa nibẹ to ãdọta, bi enia ba si ti kuro nibẹ ki oluwarẹ to kan ilu kan rara yio rin irin ọjọ kan gbako. Àgbẹ̀ ni gbogbo wọn nṣe, ọja ko si le ta nibẹ rara ni iwọn bi o ti jẹ pe ohun ti Òjó ngbin nã ni Ìlọ̀rí ngbin, olukuluku ní ohun ti o njẹ.

Ṣugbọn bi a tilẹ ti sọrọ ibẹ to yi, bi a si ti rohin talaka Òbìrí-aiye ti iṣe baba Àdììtú-Olodumare to yi, igba kan wa ti o jẹ pe o dẹ ọkunrin nã l'ọrun dãdã ati pãpã ni ọdun ti o fẹ iyawo rẹ̀, Ìpọ́njúdìran. Òbìrí-aiye dá oko lọ rẹbẹtẹ, o gbin iṣu, agbado, awujẹ, erẽ, o gbin oniruru ata gbogbo, ati ata kekere ati nla, gbogbo wọn pọ lọ bẹ̃rẹ, ni ọdun yi, iṣu Òbìrí ta bọọku, agbado yọ ọmọ bọ̀kùà, ọgẹdẹ yọ ọmọ gbàkùà, erẽ so jìnwìnnì, ìla tun so jìnwìnnì. Ẹfọ ri gbẹ̀gẹ̀gbẹgẹ, ara ohun ọgbin gbogbo l'o tutu yọ̀yọ̀ ninu oko, owo wọle fun Òbìrí lọdun nã, o pa to ogun pọnun dãdã. Lọdun keji, o pa ãdọta, ọdun kẹta, o pa apo kan o si tun pa apo kan l'ọdun kẹrin. O wa ti ṣiro bayi pe ko si ọdun kan ti ãdọta pọnun ko ni wọle fun on bi o ti wu ki owo ṣai wọle to.

Nitori eyi, inakuna ni o nna owo. Eyiti o wa buru ju gbogbo rẹ̀ lọ ni pe o ngbe ẹsẹ ga ju ibiti o yẹ.

Ẹniti o nri ãdọta pọnun lọdun nba awọn ti ngba ãdọta pọnun loṣu rin. Ẹlomiran ninu awọn ti o nba rin tilẹ le ri ãdọta pọnun lọjọ kan. Iru ọti ti nwọn nmu ni on nra sile, aṣọ ti nwọn nlo ni on nã nra s'ọrun. Bi Ìlákọ̀sẹ ko si ti ni ẹran to ti o jẹ pe ìlákọ̀sẹ ni ẹran ti o tobi julọ, sibẹ ọkunrin yi a ranṣẹ lọ si bi irin ọjọ mẹta a lọ ra ẹran. Ibiti o wa ba ohun gbogbo tì si, ti o fi sọ ara rẹ̀ di talaka gãn ni awọn obinrin ìkọ̀kọ̀ ti o tun nfẹ kiri, obinrin ti o fẹ wa sinu ile wà lọtọ̀, ti ìkọ̀kọ̀ wọnyi wà kãkiri ode. Ete awọn wọnni dun bi oyin ireke, ṣugbọn inu tobi gbẹ-ndu lasan fun kiki eke ni. Awọn ti eṣu ti gbe àkàbà itanjẹ tì l'õkan aiya, bi eṣu gun ìṣísẹ̀ kini a gun ìṣísẹ̀ keji, bi o gun ìṣísẹ̀ keji a gun ìṣísẹ̀ kẹta, a gun u titi o fi mã duro le ibi tente ọkan, asẹhinwa asẹhinbọ, nwọn ko ni le sọ ẹyọ õtọ kan pere aṣọ itanjẹ ti bo wọn lori tapatẹsẹ bamubamu. Ẹ ka iwe yi wo, ọkan ninu awọn iwe ti olufẹ ìkọ̀kọ Òbìrí-aiye kọ si i ni :





Ilu Ìlákọ̀sẹ,
Ọ̀pópó Èkéfẹ̀hìntì,
Ọjọ kejidilogun Oṣu keje
Ẹdẹgbẹwa Ọdun o le Mejidilogọta
Lẹhin Iku Oluwa wa.

Olufẹ mi ọwọn,

Ọrọ tirẹ yi ko ye mi si. Ko mà ye mi si rara o. Lõtọ, awa obinrin ti mọ ẹnyin ọkunrin pe õgun ki a ba le fẹran yin ni ẹ mã nṣe kiri ile babalawo. Ṣugbọn ibiti iwọ ti ri babalawo tirẹ yi yatọ patàpata. Njẹ o jẹ mọ pe lati alẹ àná nko fi onjẹ ba ẹnu mi yi, bẹ̃ni iwe ti mo nkọ yi, agogo mẹrin ọsan ni. Ọrọ tirẹ yi ṣa ni mo nro, bi ẹni ki nri ọ ki nri ọ l'o nṣe mi, bi o ko ba si fẹ pa mi, Òbìrí mi, werewere ni ki o jẹki nri ọ. Dandan ni ki o wa loni, mo nreti rẹ ki agogo meje alẹ to lu, bi o ba ṣiwọ oko ni marun-abọ o yẹ ki o le de ihin ki meje to lu.

Aja ile rẹ nkọ? (Gìdìgbì ori pàlàbà ẹsẹ ti o npe ni iyawo rẹ?) Maṣe ya si ọdọ rẹ̀ ki o to wa o, bi o ba ti kuro l'oko, ọdọ mi ni ki o mã bọ̀ tãra.

Ọrọ kan tilẹ wa ti mo fẹ ba ọ sọ, olufẹ mi àtàtà, olufẹ mi àpé, owo kekere kan bayi lo fẹ tẹ́ mi, awọn ọrẹ mi ti nwọn ti mọ nipa ọrọ emi rẹ si tilẹ ti nsà mi ni mẹsan mẹwa pe mo ri ẹni fẹhinti. Owo nã ko pọ, ko ju ãdọta lọ. Ki ẹ kuku mu u bọ nigbati ẹ ba nbọ o, ki o ṣe e bi ti ijọsi, ki ó jẹ owo bébà ki o rọra fi i pamọ sinu apo iwe.

Jọwọ tete de o, mo ti wa onjẹ silẹ dè ọ. Ṣe iwọ nã kuku mọ mi, ki iṣe pe awa nfọnnu, a ko jẹ se ọbẹ rederede ti olori gìdìgbì iyawo rẹ mã nse wọnni. Ati alubọsa eléwé ati oníṣu, ati tomati tutu ati alágolo, ati ata rodo ati wẹ̃rẹ, ati edé ati ẹyindiẹ—gbogbo iwọnyi ti ṣe ipade pẹlu ororo lori iké ẹran ati iwe, lori ẹ̀dọ̀ ati ahọn ati lori ibi pataki ẹran pẹpẹiyẹ. Mo din ọbẹ nã, o gbẹ.

Nitorina, mo nreti rẹ, olufẹ mi.

Emi ni tirẹ patapata,
Emi ni tirẹ t'apa t'ẹsẹ,
Emi ni tirẹ t'ori t'ọrun,
Emi ni tirẹ titi—ti, titi—ti,
Porogodo
Agbelebu—enia.

Mo fẹ ki ẹ ṣe akiyesi iwe yi, ohun ti ó pe ni "ãdọta", ki iṣe ãdọta kọbọ, ki iṣe ti ẽpinni, ãdọta pọnun ni. Iye owo ti Òbìrí ni ti o le fi tọrẹ pẹlu idẹlọrun nigbana ko ju ṣile mẹwa lọ. Wi fun mi, bawo ni enia ṣe le fi ṣile mẹwa fun ẹniti o bẽre

ãdọta pọnun ki oju má fẹrẹ ti oluwarẹ pa? Ọna bi iru eyi ni awọn alagabagebe obinrin fi ngba owo lọwọ ọkunrin yi, Òbìrí-aiye; Igbamiran pẹlu, ti nwọn ba ri i ti nwọn bẽre owo ti o wipe on ko ri, nwọn a bẹrẹsi ki ọwọ bọ apo aṣọ rẹ̀ kiri, nwọn a ki ọwọ bọ ọ ni apo ṣokoto, nwọn a ki í bọ ọ ni ti ẹwu pẹlu, nitori ifẹ olõkan ko si ninu wọn, owo ni nwọn nwa kiri.

Eyiti a ri mọ ni a si le wi, iwe ti a tẹ soke yi ṣeṣi bọ lọwọ Òbìrí-aiye silẹ ni. Ọlọrun nikan ni o le mọ iye owo ti ọkunrin nã ti ná danu le ori obinrin ikọkọ wọnyi. Ko jẹ sọ fun ẹnikẹni pe on na owo kan. Bi o fun obinrin ni pọnun kan a ni obinrin nã gãn ni o fun on ni pọnun meji. Oju a mã ti i lati sọ iru owo buruku ti on nna kiri. "Owo mi ni yi, mo le na a bi o ti wu mi, ara mi ni yi, mo le lo o bi mo ti fẹ" ki iṣe ọrọ ẹnu ọmọluwabi. Bi o ti ṣe na owo rẹ̀ ni pataki, bi o ti ṣe lo ara rẹ ni nkan.

Gẹgẹ bi a ti kọ sọ, ọja oko ko mu owo wọle fun Òbìrí-aiye bi ti atijọ mọ, igbati eleyi si pa pọ mọ ẹgbẹ nla nla ti o nko ati obinrin ti o nfẹ kiri, gbese de ilẹ rẹbẹtẹ. Igbati o di ọjọ kan, awọn ti o jẹ ni gbese ti ilẹkun ile rẹ̀, nwọn gba gbogbo apoti aṣọ patapata, nwọn gba gbogbo oko kanlẹkanlẹ, iyãra kan pere ni nwọn fi silẹ fun u.

Akoko ti nwọn fi nti ile yi, aṣọ ni Òbìrí-aiye da bora, Ipọnjudiran iyawo rẹ̀ nã ro aṣọ mọ idi.

Bi awọn ti nwọn nti ile ti lọ tan, ti awọn mejeji joko ti nwọn nwo ara wọn loju, ti ọmọ wọn ti o ṣẹṣẹ pari iwe kẹfa ni ile iwe, Àdììtú-Olodumare, nsọkun ni ẹhinkunle, ni obinrin kan tun dede wọle ti o ni afi dandan bi on gba owo ti Ipọnjudiran jẹ on ki on to lọ. Ni akoko yi, tọrọ pere ni o wa ni eti yẹri Ipọnjudiran, ṣile kan pere l'o si ku sinu apo okun ibantẹ ti ọkọ rẹ̀ san mọ idi. Igbati obinrin yi ri i pe ko si owo lọwọ tọkọtaya patapata, ti awọn miran ti nwọn jẹ ni owo nla ti ti ile ti nwọn mu kọkọrọ lọ, ṣe ni o táwọ́ si aṣọ ti ọkọ wọ si ọrun ti o gba a, ti o tun fa aṣọ idi aya ti o tu u ti o ko gbogbo rẹ̀ lọ.

Ọjọ nã ko dara ninu ile awọn tọkọtaya yi. Omi ndà pẹ̀rẹ̀ loju iyawo, ọkọ yi wọ iyara kan ti o ku silẹ fun u, o fi ọwọ ti àgbọn, o ngbin lẽkọkan. Were iyawo ti ori da ọrọ silẹ ninu





ipọnju yi, ṣe obinrin ni: "Bi mo mọ pe ijangbọn ni mo mã kàn, mo jẹ fẹ ọ? Mo jẹ fẹ oloriburuku! O sì wo mọ́ mi nã ni. O wo mọ́ mi koko, mo ja ọ titi o ko ja, alakọri, onijamba enia, ẹni ibi. A wi fun ọ, o gbọ? A ni ki o ye k'ẹgbẹ, o gba? A ni ki o ye yọ́ kẹlẹkẹlẹ ti obinrin olobinrin, ó wọ̀ ọ́ leti? Gọngọṣu, alaimero, alainironu, ọbọ lágídò lasan làsàn yi, o ku ibiti o mã wọ."

Bayi ni Ipọnjudiran bẹrẹsi bu ọkọ rẹ̀. Ṣugbọn ọna wo ni ọkunrin yi ṣe mã mã fi ba igbesi aiye rẹ̀ lọ? Ṣile kan pere ni o ni lọwọ, iyawo ni tọrọ, nwọn ni ọmọ kan lati bọ, ọmọ ọdun mẹrinlã, yẹ̀rì ni o ku si idi iyawo, o ku ibantẹ si idi ọkọ. Ilu ti nwọn si wa yi, Ilakọṣẹ, ko si ni ẹba ilu miran rara, ilu ti o sunmọ ọ ju jẹ odidi irin ọjọ kan gbako. Ewo ni ṣiṣe? Òbìrí-aiye wa oju aya rẹ̀ mọra, o gba tọrọ ti o ni, on nã mu ṣilẹ ti o ku si i lọwọ o fi mọ ọ, owo di ẹgbẽdọgbọn. Lẹhin eyi, o ke si Àdììtú-Olodumare ọmọ rẹ̀ o ni:

"Ọmọ mi, Àdììtú-Olodumare, gẹgẹ bi orukọ rẹ nã, iṣẹ ti Olodumare le ṣe, awamaridi ni, bi o ba wu Ọlọrun Ọba O le wipe titan ti de si emi ati iya rẹ, bi o wu U, O le wipe tiwa ko iti itan ninu aiye, bi o si wu U bakannã, O le wipe eyiti a ti jẹ sẹhin ni a jẹ mọ. Igbati o ba wu Olodumare, A rọ ojo silẹ, igbati o wu U, A ran õrun, O le mã ran Õrun si apa adugbo kan ki O tun mã rọ ojo si apa ibomiran lẽkanṣoṣo. Ohun ti awa ẹda le ṣe ko ju pe ki a sa ipa ẹni, ki a sa ipa tan ki a mã reti ibukun Ẹlẹda ẹni, nitori meji ni iṣẹ aiye pin si, ọkan ti enia, ọkan ti Ọlọrun Ọba. Ti enia ni pe ki a gbe omi gbona ki a da ògì si i ki o di ẹ̀kọ, ti Olodumare ni ki ó má jẹki owo ogi wọ́n ni. Nitorinã, ọmọ mi, Àdììtú, mura ni isisiyi, wa lọ si ilu ti o sunmọ ni julọ, gba owo yi, ki o lo o lọna ti ó tọ loju rẹ, lọna ti ebi ẹnu ko ni fi pa mi ku, ti ko ni fi pa ọ ku, ti ko si ni fi pa iya rẹ ku. O digba o, ọmọ mi, o digba o. Jọwọ dẹ lọla, o digba o, o digba o, o digba o."

Bayi ni baba nã ki ọmọ rẹ̀. Ṣugbọn ẹ maṣe gbagbe pe gbogbo nkan wọnyi ṣẹlẹ ni nkan bi agogo mẹwa-abọ owurọ ati pe ọmọ pãpã ko ti ifi ẹnu ba onjẹ lati ọjọ ti ilẹ ti mọ bẽni ko si ireti rara pe o le ri onjẹ rà loju ọna ni werewere. Bi o ba tilẹ ri nkọ, owo da?

Ọmọ yi mura o nlọ, bi o ba rin diẹ, a sare diẹ, bi o sare diẹ, a rin diẹ. Igbati o mã to agogo mẹjọ alẹ o ti kọja agbegbe Ìlákọ̀sẹ patapata ṣugbọn diẹ l'o fi kọja idaji irinajo rẹ̀. Kini oju rẹ̀ ṣai ri tan nigbati ilẹ ṣu? Igbati o ba ṣe, a gbọ bíbú kiniun, bi o tun ṣe, a gbọ igbe ikõko, ẹkùn kọja oju ọna lẹ̀mẹta, ejo nyọ firi niwa nyọ firi lẹhin, gbogbo itan iwin ti o ti gbọ ri, ti ọ̀rọ̀ ti o ti mọ ri, ati ti awọn oku ti o ti ku ri ti a gbọ pe a tun ri nibikan—gbogbo wọnyi nsun téré téré si i lọkan, ebi de, oṣupa dabi ọsan, o nlọ, on ati Ọlọrun Ọba, o ku on nikanṣoṣo gírogíro. Igbati o mã to agogo mejilã oru, ãrẹ de. Ọmọ yi joko lãrin inu igbo, o nwo eyiti Ọlọrun mã ṣe. Ṣugbọn orun ko mọ iku. O joko àì joko, orun mu u lọ.

Igbati Àdììtú-Olodumare fi mã ji ni ọjọ keji, agogo meje-abọ lù dãdã. Iyalẹnu l'o jẹ fun u lati ri i pe ọkunrin kan duro si ibi igberi on ti o dabi ẹni pe ó nṣọ on. O dabi ẹni pe aiye dẹ ọkunrin nã l'ọ́rùn, o wọ ẹwu danṣiki àrán, o wọ ṣokoto àrán, o si de fila àrán pẹlu. O gbe oruka gõlu gbà ngbà kan si ọmọ ika ọwọ rẹ̀ osi eyiti o duro si ipo kẹrin si atanpako. Àdììtú-Olodumare wo ọkunrin nã dãdã o ṣakiyesi pe kókó kan ti o tobi to ekurọ wa niwaju rẹ̀ lapa ọtun, ọkan ti o tun tobi to bẹ wa ni palaba eti lapa osi, lẹhin eyi, ọkunrin nã fa gbogbo irun ipenpeju patapata, ṣugbọn bi o si tilẹ da rungbọn si ti o yọ ṣọ-nṣọ ni àgbọ̀n isalẹ ó fá irun ti o bo ete oke patapata. Ọkunrin yi wa mu ọpa lọwọ ti o fi ntilẹ o si wọ salubata ti a fi awọ erè ṣe.

Bi ọkunrin yi ti wo Àdììtú-Olodumare ti onitọhun nã wo o, ti oju wọn ṣe mẹrin, ni o bi ọmọ nã ti o ni, "Iwọ ọmọde yi, ibo l'o ti mbọ ti o sun si ãrin igbo buruku yi? Ti o sun ṣa ni tirẹ lái bẹru ẹranko buruku, lái nãni ole, lái bẹru awọn ọ̀rọ̀ inu igi iroko wọnyi, lái bẹru awọn oku ti nwọn ti ku ti nwọn ko lọ s'ọrun, ti nwọn nrin kakiri ibi ìkọ̀kọ̀ ibi ìbábá gbogbo?"

Igbati o wi bayi ni Àdììtú-Olodumare nã ṣe àlàyé ti o ni: "Ilu ti mo ti nbọ ni a npe ni Ìlákọ̀sẹ, mo nlọ si ilu ti o sunmọ wa jù ti a npe ni Ìfẹ̀hìntì. Mo nlọ lati ba ra onjẹ igbẹhin fun iya ati baba mi. Ṣile kan ati tọ́rọ́ pere l'o ku sinu ile wa, on ni awọn obi mi si fun mi pe ki nlọ fi ra onjẹ ti awọn mã jẹ, bi ẹ ti ri mi yi, ibantẹ l'o kù si idi baba mi lode aiye o si ku yẹ̀rì si idi iya mi. Oni l'o di ọjọ kẹta ti mo ti fi okele si ẹnu mi yi mọ, on l'o jẹki ó rẹ̀ mi, ki nsun si ihin yi, ṣugbọn bi o ba jẹ ilẹ yin ni mo sun si, ṣe ni ki ẹ jọwọ ki ẹ dariji mi, ki ẹ jẹki nrọra mã lọ. Mo nlọ ro ohun ti mo mã fi owo ti nwọn fun mi rà ti yio ran ni lọwọ, mo nlọ bọya mo le ri alãnu ti o le na ọwọ ãnu si ile wa. Ọrọ ti mo sọ fun yin yi, nko si sọ ọ lati fi pẹgan awọn ti o bi mi, mo sọ ọ nitori a ko mọ eniti o le ran ni lọwọ nitori ẹniti o bo ijangbọn mọra si abẹ aṣọ t'on ti 'jangbọn ni yio mã rin kiri, bẹ̃ni, ẹniti o fi ijangbọn han ẹlomiran, ẹlomiran le fa a yọ ninu ijangbọn patapata."

Ọrọ yi wọ ọkunrin nã l'ọkan pupọ, o mu Àdììtú-Olodumare yà si ọna oko kan bayi. Igbati o ṣe diẹ, nwọn kan ile kan. Nwọn ko ba ẹnikẹni nibẹ rara, ṣugbọn ọkunrin nã mu akaṣu ẹkọ mẹta lori pẹpẹ, o bu ọbẹ ẹran si awo o ni ki o mã jẹun. Ọmọ yi jẹ ọkan, o yo, akaṣu ẹkọ ni gbogbo wọn. O si wa tun bẽre lọwọ alãnu rẹ̀ yi bi o ba le fun on ni aye ki on kó iyoku lọ fun awọn obi on. Ọkunrin yi wa sọrọ, o ni: "Kó gbogbo wọn lọ, mã kó wọn lọ, mo tun fi eyi kun u fun ọ (o fi mẹrin kun u)". O tun wọ inu iyãra, o mu ẹwu kan jade, o tun mu ibora aṣọ ọkunrin kan jade, o ni ki ọmọ yi fi wọn fun awọn obi rẹ̀, ki baba mã lo ẹwu, ki iya mã lo aṣọ. Lẹhin eyi wayi, o mu Àdììtú-Olodumare lọ si ibi oko kan bayi ti nwọn gbin ọgẹdẹ si lọ bẹ̃rẹ, o wi fun u pe ni ọjọ keji Ọsẹ Onigbagbọ (Monday) ni ọsọ̃sẹ ki ọmọ yi mã wa sibẹ wa bẹ́ ọgẹdẹ lọ fun awọn obi rẹ̀, Ó kàn a nipa fun ọmọ nã ṣa, pe, ko gbọdọ bẹ ju ọgẹdẹ kan lọjọ kan ati pe ko gbọdọ wa sibẹ afi ọjọ keji ọ̀sẹ lailai.

Ọrọ yi nṣe Àdììtú-Olodumare bi ala ni. O la ẹnu, kò le pa a de, igbati o si mã pa a de, o bẹrẹ ọrọ o ni, "Baba, nko mọ yin ri, bẹ̃ni nko ba yin pade lode aiye yi ri, ṣugbọn, ẹ ri mi, ẹ ko pe mi l'ọmọde, ẹ ko fi iya jẹ mi, ẹ ko si fi iwọsi lọ mi, ẹ ko wipe kini eleyi le ṣe. Bakanna ni Ọlọrun yio fi yin si ipo agba pẹlu. Owo ti ẹ o fi ṣe agba, ọmọ ti ẹ o fi ṣe agba, ile ti ẹ o fi ṣe agba, ọna ti ẹ o fi ṣe agba, aṣọ ti ẹ fi ṣe agba, ati dukia agba gbogbo ti agba fi nṣe agba, ko ni wọ́n yin lailai. Bi ẹ ti tọju mi ni Ẹlẹda yin yio mã tọju yin, bi ẹ ti kẹ mi ni Ọlọrun

o mã kẹ yin, bi ẹ ko si ti mọ baba mi, ti ẹ ko mọ iya mi, sibẹ ti ẹ na ọwọ ãnu si wọn ni Ọba Alewileṣe yio mã ṣãnu yin lailai. Mo dupẹ pupọ, mo nfẹ lọ nisisiyi wayi, lẹhin ti ọkan mi ti balẹ dãdã, si ilu ti nwọn ran mi, ni Ìfẹ̀hìntì. Ẹhín tí mo ba ra nkan tan nibẹ ni ng o wa pada si ọdọ awọn obi mi, ni Ìlákọ̀sẹ ti ng o lọ jiṣẹ ohun ti ẹ ṣe fun awọn ti nwọn bi mi. O digba, baba, O digba baba, O digba baba."

Bayi ni ọmọ na sọ ti o lọ si ilu Ifẹhinti nibiti nwọn ran a.

Igbati Olodumare ba mã ṣe nkan, ki nkan nã mã rọ̀ bi ojo ni, nkan ayọ nla l'o tun wa jẹ fun Àdììtú pe ki o to de ilu Ifẹhinti igbin nla meji l'o ri he, ẽmejẽji ti o ṣe igbọnsẹ l'o ri igbin wọnyi he, o ti kuro ni agbegbe Ilakọsẹ ni akoko nã, ṣugbọn o mọ pe owo ribiribi ni igbin nilati mu wa ni Ilakọsẹ, nitorina, o fi awọn igbin mejẽji pamọ. O de Ifẹhinti o ra iyọ kọbọ mẹrin, o wọn gãri kọbọ mẹrin, o ra ẹyọ agbado kọbọ meji, iṣana, kọbọ meji, epo, kọbọ kan-abọ, ata, kọbọ kan-abọ, o pada o di Ilakọsẹ.

Wiwọ ti ọmọ yi ni ki on wọle tọ awọn obi rẹ lọ nigbati o de Ilakọsẹ, igbe ẹkun baba rẹ l'o gbọ, "E : — e : — e : — E : — e : — e : E — e — e. Ẹ jọwọ ẹ gba mi o : — o : — o : — o : — o ! Gbogbo ara aiye, ẹ gba mi, gbogbo ero ọrun, ẹ gbà mi, gbogbo anjọnnu aiye, ẹ gba mi, gbogbo ṣigidi adahunṣe, ẹ gba mi, Ṣango, jọwọ gba mi, Ọya jọwọ gba mi, Ọbatala jọwọ gba mi, Anabi Onimale, gba mi, Jesu Onigbagbọ, gba mi. Edumare, temi dọwọ rẹ, Ọba aiku, temi dọwọ rẹ, Ọba airi, temi dọwọ rẹ, gbogbo ọmọ Ilakọsẹ, agbẹ Ilakọsẹ, oniṣowo Ilakọsẹ, ẹnikẹni ni Ilakọsẹ, ẹ jọwọ ẹ gba mi o : — : — : — : — : — : —O."

Aisan kọlu Ipọnjudiran iyawo Obiri, ni ọjọ ti Àdììtú-Olodumare kuro ni ile gãn, aisan nã bẹrẹ ko ju wakati kan ti o jade. Ṣe ni òógùn dede bo obinrin nã, ti omi bo o lara bi ẹniti ojo npa, oju rẹ̀ pupa bi õrun alẹ, ẹsẹ rẹ̀ tutu bi yìnyín, ara gbona bi idi iṣãsun ori ina, ete wu o yọ gọmbu, ẹhin tẹ̀ o ri kòlòbà, ọrun le o dabi okuta, ọwọ bẹrẹsi kuru, ọwọ di pú-ńpú, ẹsẹ ngun, ẹsẹ dabi ti àgéré, ati ṣe igbọnsẹ di nkan, ati joko di ijangbọn, ati dide di iyọnu, ati sọrọ di ọran, ati rin ko ṣẽ ṣe, ati bẹ̀rẹ̀ ko bọ si i, àwọ̀ ara kuro ni dudu, o funfun





bi ikũkũ oju ọrun, idi di pẹlẹbẹ, ikun yọ gbẹ-ndu, aiya di kẹkẹrẹ, irun ori ntu, irun ara ntu, irun abiya si ntu pẹlu—aisan buruku gbã ni.

Awọn babalawo ti pejọ bamubamu ki Àdììtú to wọle, nkan ti nwọn si nwa lati fi ṣe õgun ko ju ẹkọ lọ. Igbati ọmọ yi de ti o bẽre ohun ti nwọn nwa lati fi ṣe õgun ki aiṣan iya on le san, ohùn kan ni gbogbo wọn fi ke wipe "Akaṣu ẹkọ."

Ọmọ ba tu ẹrù, o gbe akaṣu jade. Nwọn fi agunmu fọ ẹkọ fun iya mu, nwọn tun lo èjó õgun pẹlu ẹkọ, nwọn tun wa pa itu ọwọ wọn, nwọn fi ti ajẹ fun ajẹ, ti oṣo fun oṣo, ti ẹlẹbọlõgun fun ẹlẹbọlõgun, nwọn si fi ti ṣigidi fun ṣigidi pẹlu. Ko pẹ pupọ lẹhin eyi ti Ipọnjudiran dide joko, ti Ipọnjudiran bẹrẹsi sọrọ, ti o tun di ẹniti nwọle ti njade bi ti atijọ.

Ẹhin ti ọkan gbogbo enia balẹ nipa ti Ipọnjudiran tan patapata ni Àdììtú-Olodumare to le rohin ohun ti o ba bọ. Ilẹ ọjọ keji lẹhin ti o de Ilakọsẹ ti mọ pẹlu.

Ọmọ nã ko fi ọkan pe meji, ko fi meji pe mẹta, o ro ohun gbogbo finnifinni. Iyalẹnu patapata l'o jẹ fun Òbìrí-aiye ati pãpã igbati ọmọ rẹ̀ fi ẹwu jiṣẹ fun u, ti o tun fi aṣọ jiṣẹ fun Ipọnjudiran, ti o si wa sọ pe ọjọjọ keji ọsẹ Onigbagbọ ni on o tun lọ mã bẹ ọgẹdẹ wa lati inu oko ti nwọn fi han on.

Òbìrí-aiye dahun o ni, "Ki iṣe enia l'o ri, baba mi ti o ti ku ni, ó fi ara han ọ ni. O mà ṣe o, ọkunrin nã, Ìbànújẹ́-fẹ̀hìntì, Ìbànújẹ́-fẹ̀hìntì, Ìbànújẹ́-fẹ̀hìntì baba mi, baba mi, baba mi, húù, húù, húù, húù, húù—Òbìrí-aiye nsọkun, gbogbo enia si bẹrẹsi ṣipẹ fun u.

Nkan ti o pa Òbìrí l'ẹkun ni pe nitõtọ, baba rẹ̀ ni iru kókó ti Àdììtú ṣe apejuwe niwaju, bẽni ọmọ yi ko gbọnju mọ Ìbànújẹ́-fẹ̀hìntì baba Òbìrí-aiye nitori oyun rẹ̀ l'o wa ninu nigbati o ku.

## ÀDÌÌTÚ-OLÓDÙMARÈ PADE IJANGBỌN LỌNA: NKAN ṢE

Ọmọ yi sa nlọ bẹ́ ọgẹdẹ ni ọjọjọ keji ọsẹ awọn Onigbagbọ. Igbati Àdììtú ta igbin meji ti o ri lọna ilu Ifẹhinti, o pa pọnun kan. Igbin kõkan jẹ ṣile mẹwa. Owo yĩ ni Òbìrí-aiye ati Ipọnjudiran nlo ti nwọn fi njẹun. Bi ọmọ wọn ba si ti bẹ ọgẹdẹ de lọjọ keji ọsẹ ki nwọn mã jẹ ki nwọn mã mu ni.

Ọjọ ti Àdììtú di ọmọ ọdun mẽdogun gẽre bọ si ọjọ isimi kan. Ni alẹ ọjọ yi mọju ọjọ keji Àdììtú la ala buruku kan. Bayi ni: O ba ara rẹ o nlọ lãrin inu igbo nla kan ti o kun fun oniruru igi: iroko ati ọganwo, àràbà ati ọ̀mọ̀, pó-ǹpóla ati àjẹ́kòbàlé, akòko ati pèrègún ati bẽ bẽ lọ. Bi igbo yi si ti kun fun oniruru igi ati oriṣiriṣi itakun ti ko si ẹranko kan ṣoṣo, ti ko tilẹ si okete tabi ekute, ọkẹrẹ tabi alangba, eṣinṣin tabi ẽra, bẽni ko si ẹja ninu odo ti nṣan kiri, ko si si ọpọlọ tabi akere leti odo, bẽni ko si ẹyọ akàn kan. Gbogbo agbegbe dakẹ lọlọ bi ẹnipe ọfọ nla ti ṣẹ igi on itakun gbogbo.

Àdììtú nlọ láì ri ẹnikẹni, láì gbọ ohun ẹda alaye kan titi, afi igbati o ṣe ti o dede gbọ igbe nla kan ti o gba igbo gba iju, ti o rin ilẹ̀ dòdò jakejado porogodo. Ohùn nã ke bayi, "Ì : — : — jàn : — : — gbọ̀n : — : — : — ọ̀n ! Ì : — : — jàn : — : — gbọ̀n : — : — : — Ẹbọra Ìjàngbọ̀n nbọ lọna o : — : — : — : — : — : — : — o ! Iroko inu igbo, paramọ, ọganwo inu igbo, paramọ, araba inu aginju, paramọ o ! : — : — : — : — : — : — o ! Ì : — : — jàn : — : — gbọ̀n : — : — : — : — : — : — ọ̀n !"

Bayi ni ohùn nã bẹrẹsi ke ti o nbọ ni apa ọdọ Àdììtú. Igbati o si nsunmọ ọ ju, o sa gun igi lọ. Ko pẹ pupọ lori igi ti ẹda buruku yi yọ l'ọkankan ti o ba ni lẹru gidigidi. Ipẹ bo o lara bi ara ãka, sibẹ irun hu jade lara awọn ipẹ wọnni ti ori wọn mu ti o ri ṣonṣo ṣonṣo gbogbo bi ori abẹrẹ, irun ori rẹ pọ, o si ba irun ãrin ori rẹ, ó dabi okùn o ṣàn lọ si ẹhin rẹ titi o fi kan a ni ibadi. Oju rẹ dabi oju ẹja èpìyà, ṣugbọn ọkõkan to





ti èpìyà mẹfa papọ, ẽkan ọwọ ati ti ẹsẹ rẹ gun to ẹsẹ bata kan dãdã, awọn ẽkan wọnni si wa tẹ bi gọ̀-ǹgọ́ ilu gbogbo, ori wọn mu bi abẹ, nwọn tun jọ ẽkan awodi. Ẹnu rẹ dabi ẹnu ọbọ, ṣugbọn ehin ẹnu rẹ fi ara we ti Kiniun, mariwo l'o fi bo aṣĩri idi rẹ o dabi yẹ̀rì obinrin si i ni idi o si kan a ni orunkun gàn. Ẹda yi gbe apo kan kọ apa ọtun ati ọkan kọ apa osi. Bébà owo kọrẹnsi ni nwọn fi ṣe ti apa osi patapata, ni apakan apo ti apa ọtun ni nwọn ran owo gõlu mọ kanlẹ ṣugbọn ni ekeji owo fadaka ni o bo ibẹ jakejado patapata. Ni ọrun ẹsẹ mejeji ni ẹ̀gbà idẹ wa nwọn so owo ní kọbọ kọbọ mọ ẹgba kan nwọn tun so o ní ẽpinni ẽpinni mọ ekeji, gbogbo wọnyi a mã lu ara wọn bi o ba ti nrin lọ.

Obinrin pupọ tẹle iwin yi, onirũru ni gbogbo wọn. Ọkan dudu, o ga fiofio, ko sanra ko si tẽrẹ, o mọ niwọn ; ọkan tun pupa o ga bakanna o mọ niwọn pẹlu.

Ọkan tun wa dudu, o kuru bi kukute, ko tẽrẹ ko sanra, bẽni ọkan pupa ti o kuru bi ràrá ti ko sanra ti ko si tẽrẹ. Ọkan ga dãdã, ko sanra rara, o dudu, bẽni ọkan kuru pupọ ti ko sanra ti o pupa ; ọkan tun wa ga ti o sanra pupọ ti gbogbo igba aiya rẹ ri fẹ̀rẹ̀gẹ̀jẹ̀ fẹrẹgẹjẹ ti ibadi ri ràpàtà rapata bẽ nã ni eleyi dudu, bakanna si ni eyiti o pupa ti o tun ri ràpàtà bẽ. Ọkan wà ti o pupa ti o sanra pupọ ti ko ga ju ràrá lọ bi o ba nrin afi bi ẹni pe òkètè ẹrù nyi lọ ni, bẽ nã si ni eyiti o dudu ti o ri gbirigidi bẽ ti ko ga. Ọkan ga dãdã, ko sanra, o pupa, ọkan tun kuru pupọ ko sanra o dudu.

Awọn obinrin wọnyi wa tun pin si oriṣi meji gẹgẹ bi ẹwa ara wọn, awọn kan wa ti nwọn dara lẹwa gidigidi, bi nwọn ba dudu nwọn a fi dudu wu ni, bi nwọn pupa nwọn a fi pupa wu ni, bi nwọn tẽrẹ a dabi ẹni ki gbogbo enia tẽrẹ bi nwọn sanra a dabi ẹni ki gbogbo araiye sanra, bi nwọn ga nwọn a fi giga fa ni mọra, bi nwọn si kuru, kikuru wọn a dara ṣugbọn bakanna tun ni awọn oburẹwa tun ri ni onirũru. Imu ẹlomiran a ri kurudu, ètè ẹlomiran a ri jawala, ẹnu ẹlomiran a ri pẹlẹbẹ, ete-ẹnu a ri pọn-n-pọn.

Bayi ni gbogbo awọn ti o tẹle ẹbọra Ijangbọn ri, igbati on si de ọgangan ibiti Àdììtú-Olodumare wa o gbe oju soke o ri i lori igi. O ba bẹrẹsi ọrọ isọ. "Iwọ ọmọ enia, sọkale wa, mo

fẹ lati pa ọ jẹ. Emi ni Anjọnnu Ijangbọn ti iṣe olori ogun ọba nla ti o ni aiye ati gbogbo ẹ̀kún rẹ̀, Eṣu, ẹlẹ́gbára, ọba Ọrun Apãdi. Ẹmẹrinlelogun ni mo nyi aiye po lõjọ, iṣẹ mi si ni lati mã kó bá gbogbo yin. Wo mi, mo ti ni ohun ija mi dãdã. Bi a ba da ija, aáwọ̀, ibanujẹ ati rogbodiyan ãrin ẹnyin ọmọ enia si ọgọrun ọna, marundiladọta nṣẹlẹ lori owo, marundilãdọta nṣẹlẹ lori obinrin, wo awọn wọnyi, bi nwọn ti pọ to lọwọ mi. Owo on obinrin ni ko-ṣẽ-má-ni ati ko-ṣẽ-ni inu aiye, ẹniti o ba gbọn ni o le ṣe ikawọ wọn. Ọgbọn melo ni mbẹ lori ẹnyin ọmọ enia? Dipo ki ẹ fi ẹ̀sọ̀ wa obinrin ki ẹ ba le fẹ àtàtà obinrin, iré tete ni ẹ mã nsa le wọn láì wo ẹgun iwaju ati oṣuṣu ibẹ, eleyi ni ẹ nṣe titi ẹ fi mã gbe ẹsẹ otun bọ ori ẹgun oṣuṣu ti ẹ o gbe ẹsẹ osi bọ ẹgun ọgan fun ipalara yin. Mo korira yin, mo korira yin, mo korira yin gidigidi, ati pãpã ti o tun wa jẹ pe larin awọn ẹda ko si eyiti Olodumare fẹran to yin. Mã bọ, iwọ ti ó wa lori igi, ikun rẹ bàm̀bà, ẹhin ọrun rẹ bàkimọ̀, ibadi rẹ ràpàtà yio ṣe ipade ninu iṣãsun ọbẹ mi, emi nã, Anjọnnu Ijangbọn, Anjọnnu Ijangbọn, Anjọnnu Ijangbọn."

Bayi ni iwin ná sọ, bi o si ti pari ọrọ rẹ̀ ni gbogbo awọn ero ẹhin rẹ fi ohun kan ke wipe, "Kabiyesi, kabiyesi, Olóye, Ọlọ́lá."

Àdììtú ko parada lori igi. Iwin yi duro diẹ ṣugbọn ko parada, o joko lọhun o le gongo, igbati o ṣe ni ẹbọra nã da oju ọkan ninu awọn apo ọrun rẹ̀ kọ ilẹ ti oniruru nkan buburu gbogbo bẹrẹsi jade, ejo ọka, erè, paramọlẹ ati mọ́númọ́nú. Ọ̀kùn, ekòló, ọpọlọ, akere, kan-in-kan-in, akẽkẽ, ati oniruru awọn ẹda afaiyafa buruku miran ti a ko le ka lọ bẽrẹ. Lãrin awọn ẹranko wọnyi ni ejo erè ti o wa nibẹ yọ jade, ti o nṣe làgbà, ti ó lọ́ mọ igi ti Àdììtú wa lori rẹ̀ ti o si ngun u lọ, o lọ titi o fi kan a lara. Were ti o kan a lara l'o si lọ́ mọ gbogbo ara rẹ̀ bi okùn. Titu ti o tu ṣe ni Àdììtú nbọ ni ilẹ, kerekete l'o si ba ara rẹ̀ niwaju Anjọnnu Ijangbọn láì ni ipalara kan. Bibalẹ ti o balẹ ṣe ni Anjọnnu Ijangbọn tun kó gbogbo awọn nkan buruku wọnni pada sinu apo ti o gbe e le e lori, o ni ki o mã lọ niwaju on si ibiti on ti mã pa a jẹ. Ìyà ti o tilẹ tun fi njẹ Àdììtú pẹlu ẹru ori rẹ̀ pọ gãn ni, o ṣẹ paṣan ninu igbo o bẹrẹsi na a, bi o ba si





ti na a ni paṣan kan, a ni, "Gbe ẹru rẹ nṣo ọmọ enia, tabi iwọ kọ́ l'o ni i?" Àdììtú na a dahun a ni: "Ẹrù mi kọ́, ẹbọra."

Bayi ni Anjọnnu Ijangbọn nsọ, Àdììtú nlọ niwaju, o gbe ẹru ijangbọn le ori, on nbọ lẹhin. Nwọn ṣe bẽ nwọn de idi igi iroko kan. Anjọnnu ba bẹrẹsi ro ẹjọ fun iroko o ni:

"Iroko, iwọ ni awọn ọmọ enia ńlà ṣe àga, iwọ ni nwọn ńlà ṣe ibusun, iwọ ni nwọn ńlà ṣe apoti, iwọ ni nwọn tun nfi ṣe posi oku wọn. Ko si nkan ti nwọn ko nfi oju rẹ ri. Wo eleyi, ọmọ enia, ó kó oniruru nkan buruku gbogbo, o ngbe e kiri lati ba fi ṣe ibi. Ẹrù buruku nã l'o wa lori rẹ̀ yi, njẹ mo bi ọ, o yẹ ki npa a jẹ tabi ko yẹ? O yẹ ki npa ẹniti ngbe ejo Ọka kiri lati fi ṣe ibi tabi ko yẹ? O yẹ ki npa ẹniti ngbe akẽkẽ kiri fun iṣẹ ibi tabi ko yẹ? O yẹ ki npa ẹniti ngbe paramọlẹ kiri fun ijamba tabi ko yẹ?"

Iroko ko tilẹ gbọ ti ẹnu Àdììtú, were l'o dajọ pe pipa l'o yẹ ki Anjọnnu Ijangbọn pa a. Iwin nã ko pa Àdììtú, o sa tun nti i lọ o nro ẹjọ fun oniruru igi, ko si eyiti o bẽre nkankan lọwọ ẹni keji, ti Anjọnnu ni gbogbo wọn ngbọ ti nwọn nfi dajọ igbati nwọn de ọdọ igi keje, igi òro kan, ti on tun dajọ bi ti awọn iyoku ni Anjọnnu Ijangbọn fa ọbẹ yọ, bi o ti ki i bọ ikun Àdììtú-Olodumare lati ba pa a, ṣe l'o taji loju orun. Àṣẹ́, ala ni.

Nigbati ilẹ ọjọ keji mọ, ti o jẹ ọjọ ti Àdììtú nilati lọ bẹ́ ọgẹdẹ wa, ti ó rọ́ ala yi fun iya rẹ̀, iya rẹ̀ ni ki ó má lọ, ṣugbọn igbati nwọn sọ ọrọ yi fun baba rẹ̀, Òbìrí-aiye ni ki ọmọ on lọ, ki o ṣe bi ọkunrin. Àdììtú pãpã ti pinnu dandan ati lọ.

O mura tõtọ, o lọ bẹ́ ọgẹdẹ. Bi o ti de ọhun ti o fi ada kan ọgẹdẹ ni ẹnikan dahun lati inu igbo, "Iwọ tani?". On nã fesi o ni, "Emi Àdììtú-Olodumare ni o." Ohùn nã tun bẽre o ni, "Kil'o nṣe?" On nã dahun o ni, "Mo fẹ bẹ ọgẹdẹ ni o." Ẹni nã wa bẽre o ni, "Tani ran ọ?" On tun fesi, "Baba mi ni." "Tani baba rẹ?" "Òbìrí-aiye ni baba mi." "On l'o ni ọgẹdẹ?" "Ki iṣe on o." "O ha ṣe nbẹ ọgẹdẹ ọlọgẹdẹ l'oko oloko?" "Ẹnikan bayi ti fun mi l'aṣẹ ni o." "Jọwọ sọ orukọ ẹni nã fun mi ni werewere." "Nko mọ orukọ ẹni nã rara o." Bayi, ni nwọn jọ nsọrọ si ara wọn.

Àdììtú fẹrẹ má iti isọrọ tan ti enia bi mẹrinlelogun fi jade ti nwọn mu u, ti nwọn ko ọwọ rẹ mejeji sẹhin ti nwọn dè e, ti nwọn fun u l'ókùn dan-in-dan-in. Lẹhin eyi, nwọn so ọgẹdẹ pupọ mọ ọ lọrun, nwọn tì i siwaju, gbogbo wọn kó paṣan lọwọ, nwọn nna a bi nwọn ti nlọ. Igbati o ṣe, nwọn bẹrẹsi kọrin tẹle e. Ẹnikan ni o nda orin nã. Bi o ba ti lé orin ti o wipe "Oju ole re," awọn yoku a ni "Wómù," "Aiya ole re" (Wómù); apa ole re (Wómù); ẹsẹ ole re (Wómù); ori ole re (Wómù); ọrùn ole re (Wómù); inu ole re (Wómù); ẹhin ole re (Wómù); ati bẽ bẽ lọ.

Igbati o pẹ diẹ ti nwọn ti nlọ ni nwọn dede duro ti nwọn bẹrẹsi patẹwọ ti nwọn ni ki Àdììtú mã jo. Ko fẹ lati jo rara, ṣugbọn nigbati nwọn ko paṣan bo o, werewere l'o njo ti on ti omi ti o nṣan bi àgbàrá ojo loju. Nwọn fi oju ọmọ nã ri nkan. Igbati o ba ṣe nwọn a ni ki o bẹrẹ ki ó mã ju idi ninu ijo, igbati o ba ṣe nwọn a ni ki o mã pòyì.

Eyiti o wa buru ju gbogbo iya ti nwọn fi jẹ ẹ ni pe nwọn mu u lagbara lati jẹwọ ohun ti ko ṣe. Nigbati nwọn mu u de iwaju akọwe ọba ilu Ifẹhinti, nwọn ni ki o mã wi bayi tẹle awọn bi awọn ba ti nsọ ọ: "Emi, Àdììtú-Olodumare, oloriburuku ọkunrin, mo ji ni kutukutu ọjọ aiye mi, mo gbe igba ole ka atari, mo gbe ti ọlọṣa ka ọrùn, mo de fila jagudapãli, mo nṣiṣẹ ole jẹun, mo jale titi nwọn ko ri mi mu, ṣugbọn ọjọ gbogbo ni ti ole, ọjọ kan ni ti oninkan, ni igbẹhin patapata, a ri mi mu ni oko oloko, nibiti mo ti nji ọgẹdẹ ọlọgẹdẹ bẹ, ṣugbọn dajudaju, mo mọ pe, dandan ati dandan, ni ki nwọn da ẹjọ fun mi, ki nwọn da seria fun mi, gẹgẹ bi ofin isẹdalẹ ilu Ifẹhinti." Gbogbo ọrọ wọnyi ni ó nilati sọ loju ọpọlọpọ paṣan.

Iyalẹnu ni yio si jẹ fun ẹnikẹni lati gbọ pe eleyi nã ni awọn ọlọpa Ifẹhinti yio fi ba Àdììtú ṣe ẹjọ lọjọ ti nwọn ba mã ṣe ẹjọ rẹ.

Ofin ilu Ifẹhinti le pupọ nipa ole. Ẹnikẹni ti o ba ja ole, pipa ni. Iwe Ofin Ifẹhinti ori kẹrinlelogun ẹsẹ keje ka bayi: "Iku ni iya ẹsẹ tí ole nilati jẹ. Ko si ole ti yio bọ lọwọ iya yi bi o ti wu ti nkan ti oluwarẹ ji ti kere to. Ẹnikẹni ti o ba ji ẹran yọ jẹ ninu ọbẹ iya rẹ, ole ni; ẹniti o ti ile ọkọ rẹ wa ti o gbe akaṣu ẹkọ ni ile iya rẹ lái jẹ pe a fun u laṣẹ, ole ni; ẹniti





o bu gari ara ile rẹ, lái jẹ pe o gba aṣẹ, ole ni; olẹ ni ẹniti o ji iṣu wa l'oko baba rẹ; ole ni ọmọkunrin nã ti o ji ẹwu baba rẹ wọ; ole si ni ọmọbinrin ti o ro aṣọ iya rẹ lái gba aṣẹ." Iwe Ofin Ifẹhinti ori keje ẹsẹ kẹrinlelogun si tun ka bayi: "Ni ọdun marun marun ni a o mã yan ijoye kan ninu awọn babalawo, ti o jẹ ọmọ Ifẹhinti orukọ ẹniti a o pe ni Adájọ Olè. On ni yio mã ṣe eto pipa ole gbogbo; a ki yio si so ẹnikẹni rọ lori igi, kaka bẽ, dídè ni a o de ole mọ igi ti a o si fi ada ge e l'ọrun hàù lẹ̃kanṣoṣo."

Apa isalẹ oju ewe nã tun ka bayi: "Ki Adájọ Olè to da ẹnikẹni lẹbi iku, ó nilati fi aye silẹ wadi ohun gbogbo kinni-kinni. Adajọ k'adajọ ti o ba da ẹbi iku fun alaiṣẹ, pipa ni a o pa a."

Ọjọ pẹ ti ofin ole ti wa bẹ ninu ilu Ifẹhinti, ki Ọba Alaiyeluwa Òfintótó kini to gori oye ni, bẽni Ofintoto Kejila l'o wa lori oye ni akoko ẹjọ Àdììtú yi. Igbati nwọn ti fi agbara mu Àdììtú ti o kọ orukọ ara rẹ si èjẹ ti nwọn fi agbara mu u jẹ tan, ni akọwe ti fi i fun awọn ti ntọju ile ẹlẹwọn ibẹ ki nwọn sọ ọ sinu tubu di ọjọ ti nwọn o ṣe ẹjọ rẹ.

Baba Àdììtú ko gbọ nkankan rara ni ile ṣugbọn nigbati o di ọjọ ti o yẹ ki o de ti ko de, ti o tun di ọjọ keji ti ko ri i, on nã ki ẹsẹ si ọna o wa ọmọ rẹ lọ.

Ọjọ ti nwọn nilati pa Àdììtú ni baba rẹ de si Ifẹhinti. Iṣẹju kan pere l'o ku ki nwọn bẹ ọmọ rẹ lori lãrin ọja l'o yọ si wọn. Nkan ti nwọn ṣe gẹgẹ bi isẹdalẹ wọn yio fi han yin bi eto ole pipa ti mã nri ni ilu Ifẹhinti.

Lọjọ yi, ni nkan bi agogo mẹjọ-abọ gbogbo enia ti pe si arin ọja patapata. Igbati Adajọ Ole mã jade, o wọ ẹwu oye rẹ. Kijipa funfun ni nwọn fi ran ẹwu nã ni gbàrìyẹ̀. Nwọn so ẹyọ owo mọ ara rẹ kanlẹ. Lẹhin eyi, nwọn ran ọpọlọpọ àdó ati atọ mọ ọ, nwọn si tun wa so iyẹ ẹiyẹ, ori ẹiyẹ ati egungun ejo mọ ọ lara dígbọndìgbọn, nwọn ṣe iwọnyi ni ọna ti o jẹ pe gbogbo alafo ara aṣọ nã dí patapata.

Ibiti ko ba si ẹyọ owo, àdó mbẹ, ibiti ko si àdó, atọ wa, ibiti atọ ko si, iyẹ ẹiyẹ tabi egungun ẹiyẹ wa pẹlu.

Ọba de si ori itẹ rẹ ni agogo mẹsan gẽre. O de ade, o wọ bata ilẹkẹ, o gbe agbari enia meji kọ ọrùn, ó kọ oju agbari

kan siwaju o kọ ti ikeji sẹhin, eyini ni pe ẹhin rẹ̀ ko kan aga.

Adajọ Ole fa Àdììtú lọwọ lọ siwaju ọba, o dahun o ni, "Kabiyesi, Alaiyeluwa, Alaṣẹ, Ekeji Oriṣa, Iku Bàbá Yèyé, Oba Òfintótó ti o ju gbogbo ọba lọ, a ri ole yi mu ninu oko, o nji ọgẹdẹ bẹ́."

Ofintoto dahun bayi : "Njẹ o ti wadi dãdã ó si da ọ loju pe ó ṣe bẹ̃?"

Adajọ Ole ni, "Mo ti wadi, awọn ẹlomiran si ti wadi pẹlu. A ba a nibiti o ti nbẹ ọgẹdẹ gãn, oloko wipe on ko fun u l'aṣẹ, on ní ẹnikan fun on l'aṣẹ lati ṣe bẹ̃, njẹ a bẽre ki o sọ ẹni nã fun ni, ṣugbọn ko le sọ ọ, a ba mu u bi ole, Kabiyesi."

Ọba wa paṣẹ : "Fi han gbogbo ilu, si ṣe idajọ fun u gẹgẹ bi ofin atọwọdọwọ wa."

Lẹhin eyi ni Adajọ Ole paṣẹ ki awọn iranṣẹ ni afin ṣe eto bi o ti yẹ. Nwọn gbe ìkẹ́ igi nla kan jade, nwọn bọ ẹwu l'ọrun Adiitu, nwọn mu u kunlẹ, o gbe ọrun rẹ̀ le ìkẹ́ igi yi, nwọn wa gbe irin nla kan le e ni orunkun ti o mu ẹsẹ rẹ̀ mọlẹ dãdã, nwọn si gbe oruka irin nla kan le e ni ibi ipakọ ti o fa ori siwaju ti ọrun nikan wá wà lori ìkẹ́ igi.

Awọn ọdẹ ati babalawo tò yi ibiti ọmọ yi wà ka. Lẹhin eyi ni Adajọ Ole gbe mariwo ọpẹ nla kan ti o na a mọlẹ ni ẹ̃kini, bi o ti ṣe bẹ̃ o ke lohun rara o ni, "Ẹnyin ọmọ ilu Ifẹhinti-i-ò : — : — : — ò." Gbogbo awọn ero iworan ati awọn babalawo dahun nwọn ni, "Hè-é-ò : — : — : — ò." O tun na mariwo ọpẹ mọlẹ lẹ̃keji o ke bi ti iṣãju, gbogbo enia nã fesi bi ti iṣãju. O na a mọlẹ ni ẹ̃kẹta, gbogbo wọn tun dahun lẹ̃kẹta.

Igbati o ke lẹ̃kẹrin ti gbogbo wọn dahun, o ni, "Àdììtú-Olodumare, ọmọ Ilakọsẹ, alejo ni ilẹ yi, ji ọgẹdẹ bẹ́ ni oko oloko a si fẹ pa a, gẹgẹ bi ofin isẹdalẹ wa. Ẹnikẹni ti o ba ri idi rẹ̀ ti a ko fi gbọdọ pa a ki o sọ nisisiyi, bi bẹ̃ kọ, ki o pa ẹnu rẹ̀ mọ lailai."

Gbogbo enia dakẹ minimini, Adajọ Ole tun na mariwo ọpẹ mọlẹ lẹ̃karun o ni, "Àdììtú-Olodumare, ọmọ Ilakọsẹ, alejo ni ilẹ yi, ji ọgẹdẹ bẹ ni oko oloko a si fẹ pa a, gẹgẹ bi ofin isẹdalẹ wa. Ẹnikẹni ti o ba ri idi rẹ̀ ti a ko fi gbọdọ pa a ki o sọ nisisiyi, bi bẹ̃ kọ, ki o pa ẹnu rẹ̀ mọ lailai."





Bi Adajọ Ole ti nke ti o nṣe ifilọ bayi ni ẹniti o nilati pa ole gbe ada soke. O ku ẹ̃kan ṣoṣo wayi ti o jẹ pe bi ẹnikẹni ko ba dahun lẹhin ti ó dakẹ ki nwọn bẹ ori Àdììtú sọnu ni.

Ṣugbọn Òbìrí-aiye ti o ti nwa ọmọ rẹ̀ bọ lati igbati o ti kuro ni Ilakọsẹ de si ãrin awọn ero gãn ni Adajọ Ole pari ifilọ ekeji. Igbati o pari ifilọ kẹta pe "Àdììtú-Olodumare, ọmọ Ilakọsẹ, alejo ni ilẹ yi ji ọgẹdẹ bẹ ni oko oloko, a si fẹ pa a, gẹgẹ bi ofin isẹdalẹ wa. Ẹnikẹni ti o ba ri idi rẹ̀ ti a ko fi gbọdọ pa a, ki o sọ nisisiyi. Bi bẹ̃ kọ, ki o pa ẹnu rẹ̀ mọ lailài," iré ni Òbìrí-aiye sa jade lãrin ero lẹhin ti o dahun lohun rara pe "Emi ri o : — : — : — o," ti o bẹ siwaju Adajọ Ole. Gẹgẹ bi aṣa, nwọn nilati wadi ohun ti o ri.

Gbogbo enia ta giri, ọba pãpã dide, ẹniti o gbe ada soke gbe ada silẹ. Òbìrí-aiye ba ọmọ rẹ̀ nibiti nwọn de e si, diẹ l'o ku ki omi bọ loju rẹ̀, ṣugbọn o ṣe ọkan ọkunrin, o kọju si Adajọ-Ole o ni "Ọmọ mi ni yi, ko jale rara, ko ji ọgẹdẹ bẹ, ẹnikan ti o ri i loju ọna nigbati mo ran a wa si Ifẹhinti ni o fun u l'aṣẹ ki o wa mã bẹ ọgẹdẹ ninu oko ti ẹ ti mu u. Dajudaju, ati emi, ati ọmọ mi ṣebi oko ọkunrin nã ni."

Gbogbo ẹniti o gbọ ọrọ yi ke l'ohun kan "Darukọ ẹni nã, darukọ ẹni nã fun ni."

Ṣugbọn nwọn de Àdììtú mọlẹ nibiti o wa ni, ko le la ẹnu rẹ̀ sọrọ kan rara. Adajọ Ole ba lọ si ọdọ ọba o gba aye ki nwọn tu ọmọ nã silẹ ki o ri aye sọrọ diẹ. Ero rẹ̀ ni pe ki o sọrọ diẹ ṣa ki awọn to pa a ni, nitori o ti sọ ohun ti baba rẹ̀ yi sọ tẹlẹ ri, ṣugbọn ài le darukọ ẹniti o fun u l'aṣẹ ki o wa mã bẹ ọgẹdẹ ni oko ti nwọn ti mu u ni ko jẹki nwọn gba a gbọ.

Nwọn ba tu Àdììtú. Adajọ Ole ba bẽre bayi : "Ngbọ, otọ ni ẹnikan fun ọ l'aṣẹ lati lọ bẹ ọgẹdẹ ọlọgẹdẹ ni oko oloko?" Àdììtú dahun o ni, "Õtọ ni."

Adajọ tun nba ọrọ rẹ̀ lọ o ni, "Bi ó ba jẹ õtọ ni, njẹ darukọ ẹni nã ki gbogbo wa gbọ."

Àdììtú ni, "Nko mọ orukọ rẹ̀."

Adajọ Ole wa wo Òbìrí-aiye loju, o mi ejika rẹ̀ o ni, "Ko pari?"

Òbìrí ni "Ko pari kan rara, jẹki emi tun ṣe ibẽre kan si i," Òbìrí wá bi ọmọ rẹ̀ o ni, "Njẹ bi o ba ri ọkunrin nã, o le mọ

ọ bi?" Àdìitú ni, "Mo le mọ ọ dãdã." Òbìrí tun nba ọrọ rẹ lọ o ni, "Ṣe apejuwe nkan ti o le ranti lara ọkunrin ti o fun ọ l'aṣẹ yi."

Àdìitú-Olodumare ba bẹrẹ o ni, "Mo ranti pe ọkunrin nã ki iṣe enia kekere rara, nitori aṣọ ti o wọ ki iṣe kekere, aṣọ àrán dãdã ni; ṣugbọn ó ní kókó kan bayi ni ibi iwaju ori. Kókó nã gùn to bayi (o fi ọkan ninu awọn ọmọ ika ọwọ rẹ diwọn). Ó dá rungbọn si ni àgbọ̀n isalẹ ṣugbọn irun ti isaba mã hu ni ete oke ko si nibẹ, o fa ete oke dan patapata. Ko si irun kan rara ni ipenpeju, bọrọgidi l'o ri. Eyiti mo ranti mọ nipa ọkunrin nã ni eyi."

Ọrọ de ilẹ wayi. Ẹnikan ṣoṣo l'o wa lãrin ilu Ifẹhinti ti o ni iru kókó tị Àdìitú ṣe apejuwe, ẹni nã si ni igba keji ọba, ṣugbọn ko si nibẹ ni ọjọ ti nwọn nṣe ẹjọ ọmọ nã, bi o tilẹ jẹ pe o ti ngbọ finrìnfinrìn nipa rẹ.

Ọba pãpã fura diẹ nisisiyi pe õtọ ni ọrọ ti ọmọ nsọ pe ẹnikan l'o fun on l'aṣẹ ati pãpã ti ó jẹ pe oko igba keji ọba yi ko jina si ibiti nkan ti ṣẹlẹ. Ọba paṣẹ pe ki gbogbo ilu tuka, ki nwọn da Àdìitú pada fun baba rẹ, ṣugbọn o kilọ fun awọn mejeji, ati baba ati ọmọ pe nwọn ko gbọdọ kuro ni arin ilu titi on o fi fun wọn l'aṣẹ.

Ni gbogbo ilu ni ode aiye yi ko si eyiti awọn enia inu rẹ mọ iṣẹ àfọwọ́ṣe bi ilu Ifẹhinti. Bi nwọn fi amọ̀ mọ enia, igbati oluwarẹ ba sọrọ si i ti ko dahun ni yio to mọ pe amọ̀ ni. Igbati Adiitu ṣe apejuwe ẹniti o fun on l'aṣẹ ati mã bẹ ọgẹdẹ yi, ko si ẹniti ko fi inu wipe igba keji Ọba ni. Ko si ẹni nã ni gbogbo ilu ti o ni iru kókó ti Àdìitú ṣa-pejuwe afi on.

Ṣugbọn ọran nla ni pe ki enia mu igba keji ọba l'ole. Ọba yan awọn ọlọgbọn mẹfa kan pe ki nwọn ṣe ipade lori ọran nã ki nwọn wa sọ fun on ohun ti o yẹ ki on ṣe.

Igbati awọn ọlọgbọn ṣe iwadi, imọran ti nwọn fun ọba ni pe ki o bi igba keji rẹ bi o ba jẹ pe, lõtọ, on l'o fun Àdìitú ni aṣẹ ati lọ mã bẹ́ ọgẹdẹ ni oko oloko. Ọba ranṣẹ si igba keji rẹ ki o wa fi oju kan on lõtọ. Igbati o de, ti ọba wadi lọwọ rẹ, o sẹ kanlẹ bamubamu.

Ni gbogbo akoko yi, nwọn ko jẹki Àdìitú fi oju kan ọkunrin nã rara. Ni ilu Ifẹhinti, irungbọn didasi ni ọkunrin ibẹ fi nṣe





fãri, ṣugbọn ko si ẹniti o nda rungbọn agbọn isalẹ si ti o nfa irun ti o hu si ete oke. Bayi ni ọkunrin nã ṣe lọjọ ti o ṣi ọmọ ọlọmọ lọna, ṣugbọn eleyi ti ṣẹlẹ to oṣu mẹfa dãdã ati irun ti o fa ni ete oke ati ti ipenpeju, gbogbo wọnyi ti hu pada ti ko si ẹniti o tun mọ pe ẹnikẹni fá wọn ri.

Awọn ọlọgbọn ilu wa lọ wa enia mẹtalelogun ti o jọ igba keji ọba pupọ ti o jẹ pe bakanna ni nwọn ga mọ, iwọn kanna ni nwọn tẹ nigbati a gbe wọn ka ori ìwọ̀n, nwọn wa fi amọ̀ ṣe kókó ti o dabi ti igba keji ọba gãn si ori wọn, ni ọgangan ibiti kókó igba keji ọba wà. Lẹhin eyi, nwọn wa paṣẹ pe ki gbogbo awọn mẹtẹtalelogun ati igba keji ọba fa irun ete oke ati ti ipenpeju. Nwọn wa to gbogbo awọn wọnyi tẹle ara wọn, ibiti igba keji ọba wà jẹ ipo kẹta si ẹniti o gbẹhin patapata. Nwọn ni ki nwọn rin kọja niwaju Àdìitú-Olodumare. Ẹni kini kọja, Àdìitú ko mu u, àtẹ̀lé kọja, ko mu u, gbogbo wọn sa nkọja ṣa, ko mu wọn, igbati o kan igba keji ọba, were l'o mu u "On ni yi, on ni yi, on ni yi" ni Àdìitú nke.

Were ni nwọn paṣẹ ki ọlọpa mu igba keji ọba. Nwọn fa a le Adajọ Ole lọwọ ki o da ẹjọ iku fun u.

Gẹgẹ bi eto oye jijẹ ni ilu Ifẹhinti ko si pe a npe ẹnikan ni Balogun tabi Ọtun, tabi Ọtun-Balogun tabi Osi-Balogun, ko si pe ẹnikan njẹ Lisa tabi Ṣàṣẹ́rẹ́ tabi Ọjọmu, ko si Baṣọrun tabi Agbakin, ko si Seriki tabi Àgòrò. Ọba nikan ni a npe ni ọba, lẹhin eyi ni nwọn wa to orukọ wọn bi nwọn ti ni ipo ju ara wọn lọ bayi, Igba keji Ọba ni Ekeji Ilu. Lẹhin rẹ ni Ẹkẹta Ilu, Ẹkẹrin Ilu, Ẹkarun Ilu, Ẹkẹfa Ilu, Ekeje Ilu ati bẹ̃ bẹ̃ lọ. Iwọnyi l'o jẹ orukọ oye wọn.

Ọkan ninu awọn ofin ilu Ifẹhinti ti o wa ni ori kọkanlelogun, oju ewe kẹwa ninu iwe ofin ka bayi : "Ijoye ti o bã mu ki ọmọnikeji jale nilati ku. Bi ọba ko ba fẹ ki ijoye nã ku a fun ọba laṣẹ ki o yi eyi pada si iyakiya ti o ba wu u."

Ofin keji ti o wa loju ewe kẹjọ iwe ofin tun ka bayi : "Ko si ijoye ti o gbọdọ dá nikan ku ni ilu Ifẹhinti. Bi ijoye ba ku iku atọrunwa, igbimọ nilati pa ẹnikan larin ilu ki nwọn sin i pẹlu rẹ. Bi ijoye ba ṣe nkan ti o jẹ pe a fi da ẹjọ iku fun u, ijoye bẹ̃ nilati darukọ ẹniti yio ba on ku, ẹnikẹni ti o ba si darukọ larin ilu nilati ku pẹlu rẹ ni. Bi ọba ba ku, enia mẹrin

nilati ba a ku, bi o ba si jẹ pe a da ẹjọ iku fun ọba, on tikararẹ nilati darukọ awọn mẹrin ti yio ba on ku ni."

Iru ofin bawọnyi le ya ẹnikẹni lẹnu ni ode oni, o tilẹ le dabi nkan ti ko le jẹ õtọ loju awọn ọmọ ile iwe, ṣugbọn ofin ti o de isinku Ọba ni arin awọn Yoruba ni aiye atijọ fi ara we e. Ọba kan ko gbọdọ ku ki ẹrú tabi obinrin rẹ kan má ba a ku, o sa jẹ pe nwọn ko nsaba darukọ ẹniti awọn ba nfẹ ki o ku pẹlu awọn ni. Sibẹ nã, ẹrú tabi aya ọba ti o sunmọ ọ ju ni igba aiye rẹ ni o mã nba ọba ku. Ki iṣe arin awọn Yoruba nikan ni aṣa yi ti gbilẹ, awọn ọlọgbọn ti wi fun ni pe ko si Farase Ọba Egipti kan ti o nnikan ku láì jẹ pe ẹnikan ba a ku ni aiye atijọ.

Ṣugbọn nwọn ko da ẹjọ nã ni ọjọ yi, ọba paṣẹ ki nwọn ju Ekeji Ilu si ẹwọn titi nwọn o fi ṣe ẹjọ rẹ. Ó da ọjọ mẹsan fun ẹjọ nã.

Igbati ọjọ pe, Adajọ Ole ti ṣe gbogbo eto. Nwọn ti to awọn babalawo ati ọlọ́dẹ yipo ibiti a o ti pa Ekeji Ilu, nwọn si ti gbe ìtí igi ti a o so o mọ, ẹniti yio bẹ́ ẹ ti gbe ada lọwọ, ọba pãpã ti gunwa o nreti pe ki nwọn bẹ́ Ekeji Ilu lori.

Adajọ Ole ti o ti wọ ẹ̀wù oye rẹ̀ fa Ekeji Ilu wa siwaju ọba o ni, "Kabiyesi, Ekeji Ilu ni yi, on ni igba keji yin, on l'o mu ki Àdììtú-Olodumare bẹ ọgẹdẹ ọlọgẹdẹ láì jẹ pe ọlọgẹdẹ fun u laṣẹ ki o ṣe bẹ̃. Ofin atọwọdọwọ wa si ka bayi pe: 'Ijoye ti o ba mu ki ọmọnikeji jale, nilati ku. Bi ọba ko ba fẹ ki ijoye nã ku, a fun ọba laṣẹ ki o yi eyi pada si iyakiya ti o ba wu u,' nitorina, Kabiyesi, ẹ fẹ ṣe ayipada tabi ẹ ko fẹ?"

Ọba ko sọrọ. O bẽre lẹkini, o bẽre lẹ̃keji, o bẽre lẹ̃kẹta, ọba ko gbin. Bi ọba ko ba ti sọrọ bẹ̃, eyini ni pe o nfẹ ki nwọn dajọ fun ẹni nã gẹgẹ bi ofin. Ọba fẹ eleyi ni pataki nigbana nitori on ati ijoye nã kò rẹ́ ju bẹ̃ lọ.

Adajọ Ole ba mura ati de Ekeji Ilu mọlẹ, nwọn tilẹ ti ngbe e dubulẹ ni o ranti pe ko gbọdọ ku láì jẹ pe o fi ẹnu ara rẹ̀ yan ẹniti yio ku pẹlu on. O ba kọju si Ekeji Ilu o ka iwe ofin ti o wi bayi fun u pe: "Bi ijoye ba ṣe nkan ti o jẹ pe a fi da ẹjọ iku fun u, ijoye bẹ̃ nilati darukọ ẹniti yio ba on ku, ẹnikẹni ti o ba si darukọ lãrin ilu nilati ku pẹlu rẹ̀ ni." Adajọ Ole ba tun nba ọrọ rẹ̀ lọ o ni, "Nisisiyi, Ekeji Ilu, o ti ṣe aṣe-má-ṣe, o gbagbe ipo rẹ o si ja sinu kanga; o ṣi ọmọnikeji rẹ lọna, o fi





oko oloko fun ẹni ẹlẹni, Babalawo ilu dajọ fun ọ, Oloriṣa ilu dajọ iku fun ọ, Ṣàngó ilu dajọ iku fun ọ, Ọya ilu dajọ iku fun ọ, egúngún ilu dajọ iku fun ọ, orò ilu dajọ iku fun ọ, awọn oṣo ati ajẹ, gbogbo ẹlẹbọlõgun patapata, lọmọde, lagbalagba, lọkunrin, lobinrin, ati gbogbo arugbo porogodo, gbogbo wọn l'o dajọ iku fun ọ. Gẹgẹ bi ofin wa, Ekeji Ilu, ki ori rẹ to kuro l'ọ́rùn rẹ, wi fun ni, tani ki o ku pẹlu rẹ?"

Bayi ni Adajọ Ole sọ gbogbo enia si nreti ọrọ ikẹhin ẹnu Ekeji Ilu, on na bẹrẹ o ni,

Gbogbo ilu, mo ki yin o, arugbo ilu, agba ilu, ọmọde ilu, ọkunrin ilu, obinrin ilu, oṣo ilu, ajẹ ilu, gbogbo yin ni mo ki patapata. (O wa kọju si ọba) Kabiyesi, mo ki yin lọpọlọpọ, ọjọ pẹ ti emi ati ẹnyin, Alaiye, ti nbọ, a ti jọ njẹ a ti jọ nmu, a ti jọ ngbimọran pọ, a dabi ahọn on ẹnu, a kò gbọ pe ẹnu lọ sibikan ahọn ko lọ ri, Kabiyesi, ẹnyin ni mo fẹ ki ẹ ku pẹlu mi."

Nigbati o wi bayi, gbogbo enia kùn lọ hùn-ùn, ẹlomiran ni, "Irọ ni, ofin ko mu Ọba", omiran ni, "Eke ni, ẹnikẹni ko ku ki Ọba ba a ku ri, ko si bẹ̃ ninu iwe ofin" ati bẹ̃ bẹ̃ lọ.

Ṣugbọn, nkan ti ofin wi ni, "Ẹnikẹni ti ó ba si darukọ lãrin ilu, nilati ku pẹlu rẹ̀." Ofin ko mu ọba kuro.

Inu ọba dàrú, o wi fun Adajọ Ole ki o tun iwe ofin yẹ̀ wò, on nã bẹrẹsi wa inu iwe wàràwàrà nwọn wa a titi, ko si ohun ti o le yọ ọba. Ọran wa di ki ọba mã mura ọrun, òógùn bo o lati ori de atẹlẹsẹ, lati ekiti idi de gẹ̀-ǹgẹ̀ aiya, omi njade lati inu iho eti ọba.

Gẹgẹ bi aṣa ilu nã, ọjọ nã gãn ni ọba nilati ku pẹlu Ekeji Ilu, ṣugbọn dandan ni pe ki ó sọrọ idagbere fun awọn ti o duro, Ọba ba dide, igbati o mã sọrọ, afi bi akololo ǹi, o ni, "M-m-m-ḿ mo d-d-d-d-du pẹ o, gbogbo ilu. Bi nkan ba ti de, o de nã ni. Ẹniti o to mi ni ilẹ yi ti ku, eyiti o ju mi lọ ti ku, eyiti o ṣe iwọn mi gãn ti ku, eyiti ko si to mi ti ku pẹlu. Bi ó ba ti wu ẹniti o da ni l'o nṣe nkan rẹ̀. Mo ṣetan lati lọ, lati lọ si ibiti awọn baba ẹlomiran ti lọ, lati lọ si ibiti baba temi pãpã ti lọ. Bi mo ti nlọ ẹ jọwọ ẹ tọju awọn nkan mi, ki ẹ tọju ọmọ, ki ẹ tọju awọn iyawo, ki ẹ tọju oko, ki ẹ tọju awọn ohun ọsin mi, ki ẹ pin ogun mi dãdã, ki ẹ fi agbádá fun

ẹniti agbádá tọ si, ẹ fi bùbá fun ẹniti buba yẹ, ẹ fi ṣokoto fun ẹniti o yẹ fun ṣokoto, ẹ má si ṣe fi dandogo mi fun enia yẹpẹrẹ. O digba, o di lilọ, ẹ gbe ìké igi wa, ẹ di ọrun mi mọ ọ, ki ẹniti yio bẹ́ mi mura giri, ẽkanṣoṣo ni ki ẹ bẹ ọrun mi hàù, ki ori buruku takiti lọ—he ! he ! he ! he ! he ! he ! — ọba bu si ẹkun.

Nigbati ọba pari ọrọ sisọ ti o si dakẹ ẹkun tan, Adajọ Ole wi fun u ki o darukọ ẹni mẹrin ti yio ba on ku, ọba ba kọju si Ẹkẹta Ilu, o bẹrẹ ọrọ o ni :

"Ọrẹ mi tõtọ, iwọ ni igbá ẹhin mi, emi ni ijapa. Ko si ibiti mo lọ ti mo fi ọ silẹ ri, lọjọ ayọ, a jọ yọ, lọjọ ebi, ebi jọ pa ni, lọjọ ijo, a jọ jo, lọjo ẹ̀rín a jọ rẹrin, lọjọ ẹkun a si jọ sọkun ni. Igba iku de ná wayi, dandan ni ki iku jọ mu wa lọ. Adajọ Ole, mo yan Ẹkẹta Ilu ki ó ba mi lọ si ọrun alakeji."

Bayi ni ọba sọ si Ẹkẹta Ilu, oju onitọhun nã bẹrẹsi pupa bi õrun alẹ lẹsẹkẹsẹ, ọba ba tun kọju si Ẹkẹrin Ilu, o bẹrẹ ọrọ, ọba ni "Ẹkẹrin Ilu, Ẹkẹrin temi, Ẹkẹrin pataki, Ẹkẹrin àtàtà, Ẹkẹrin nla, Ẹkẹrin ti o ju Ẹkẹrin lọ, akoko ẽrun, o yatọ si akoko ojo, akoko ọyẹ o yatọ si akoko òwọ̀rẹ́, akoko gbigbin, o yatọ si akoko ikore ; akoko ẹkun, o yatọ si akoko ayọ ; akoko iṣẹ o yatọ si akoko isimi, ko si si eyiti o le ṣẹlẹ ninu awọn nkan wọnyi pọ lẽkanṣoṣo, akoko wọnyi gbogbo ni emi ati iwọ ti lo pọ ri, a ti jọ rẹrin pọ, a ti jọ fa oju ro, a ti jọ mu omi, a ti jọ mu ọti, a si ti jọ mu akengbe ẹmu pọ ni afin, iwọ ọrẹ mi, akoko iku de loni wayi, a mã jọ ku ni :

"Adajọ Ole, mo yan Ẹkẹrin Ilu ki o ba mi lọ si ọrun alakeji."

Ọba tun kọju si Ẹkarun Ilu, o ni, "Ẹkarun Ilu, Ẹkarun temi pãpã, iwọ, igi jẹ́gẹ́dẹ́, igi àràbà, ẹniti a ro pe ko le pa agọ, igi jẹ́gẹ́dẹ́ o ṣe bi ire bi ire o kọ aruru, o ṣe kẹ̀rẹ̀ kẹ̀rẹ̀ o di baba agbalagba. Ẹlomiran wa ni ode aiye, yanrin ni Ẹlẹda fi da a, ko lagbara ; omiran wà, àbàtà ni Ẹlẹda fi da a, ko lagbara. Ṣugbọn, Ẹkarun Ilu, o ko si ninu awọn wọnyi, ohun ti Ẹlẹda rẹ fi da ọ, akọ okuta ni. Mo nmu ọ lọ, ki a jọ kẹgbẹ lọ si ode ọrun, Adajọ Ole, mo yan Ẹkarun Ilu ki o ba mi lọ si ọrun alakeji."

Nigbati ọba sọ bayi tan, o kọju si Ẹkẹfa Ilu, o ni, "Ẹkẹfa temi pãpã, lati ọjọ ti o ti jẹ Ẹkẹfa Ilu, ẽfa rẹ ko fa ijangbọn wale ri, ẽfa rẹ ko fa aisan wale ri, ẽfa rẹ ko fa rogbodiyan





wale ri, ẽfa ni o fi nfa ilọsiwaju fun aja ilu, on ni o fi nfa ilọsiwaju fun ẹran ilu, on ni o fi nfa owo wọle, on ni o fi nfa ọmọ. Bi mo ti ri ire ninu aiye, mo fẹ ri ire l'ọrun, nitorina, mo nilati mu ọ lọ, ki o fi ẹfa rẹ fa rere tẹle mi de ode ọrun, Adajọ Ole, mo yan Ẹkẹfa Ilu ki o ba mi lọ si ọrun alakeji."

Bayi ni gbogbo nkan wa lọ ti o di pe ijoye mẹfa nilati ku ni ilu Ifẹhinti. Ṣugbọn ẹ maṣe gbagbe pe gbogbo awọn ti o mã ba ọba ku yi ko gbọdọ ku ni awọn nikan. Ẹnikọ̃kan ninu wọn nilati sọ ẹniti yio ba on ku ki o to di pe o ku.

Ati Adajọ Ole ni o, ati awọn ọmọ ilu Ifẹhinti ti o duro ni o, ko si ẹniti o mọ ọna ati yọ ninu ọran ti o de ilẹ yi. Ninu awọn ijoye ti o nilati ku, iyekan ẹniti o nilati bẹ́ wọn lori wà, ọbàkan rẹ̀ wa, Adajọ Ole pãpã ko mọ nkan ti on le ṣe. Gbogbo enia dakẹ minimini, nwọn nwo ohun ti Adajọ Ole yio ṣe, ẹnikẹni ko gbin, ẹnikẹni ko sọrọ, oju gbogbo kan gbínrín-gbínrín, o kan ju ọbẹ̀ itadogun lọ. Igbati o ṣe ni Adajọ Ole kọju si ọba ti o bẹrẹ ọrọ, o ni :

"Kabiyesi, mo ti ronu jinlẹ patapata, mo ti ronu jinlẹ pupọpupọ, mo ti ronu jinlẹ gidigidi. Mo ti de inu aiye yi to igba kan, lati igbati ilu si ti fi mi jẹ oye yi, ó ní iye ẹjọ ole ti mo ti da. Loni, Kabiyesi, mo ro pe ọran ti o de ilẹ yi ki iṣe nkan àkùgbùrù ṣe, ọran ti o gba ironu ni, gafara ti mo si fẹ tọrọ lọwọ yin ni pe ki ẹ fun awọn èwe ilu Ifẹhinti ni ọjọ mẹsan gbako ki nwọn fi lọ ronu ọran yi :

"Àbá mi ki iṣe pe ki ẹniti ofin ba wipe ki o ku má ku. Ero mi tilẹ ni pe ki gbogbo ẹnyin ijoye wọ aṣọ ti ẹ o mu lọ si ọrun wa pade wa. Ki o to di ọjọ mẹsan nã, ẹ o ti pin awọn ohun ini yin gbogbo fun awọn ti ẹ fẹ, ẹ o ti ṣe eto oko ati eto ile, ẹ o ti ṣe ti ọmọ ati ti aya ẹ o ti ṣe ti ọrẹ, ẹ o si ti ṣe ti ojulumọ pẹlu. Ẹ o wa sihin yi, nireti pe ọjọ nã l'ẹ ti ri ile aiye mọ, Kabiyesi."

Ọrọ ti Adajọ Ole sọ yi ye ọba dãdã, o si dun mọ awọn ijoye ninu diẹ pe aye wa fun awọn lati ṣe eto ile awọn. Ọba gba bi Adajọ Ole ti wi, o fun awọn ọmọde ilu ni aye ọjọ mẹsan ki nwọn fi ṣe eto iku awọn.

Ṣugbọn lãrin ọjọ mẹsan nã, idãmu de ba gbogbo awọn ti nwọn ti da ẹjọ iku fun, nwọn ri onjẹ, nwọn ko le jẹ, nwọn ri ohun mimu nwọn ko le mu, ironu de ba wọn, nwọn di jánna-

jànna, igbá aiya ti o ti ri gbẹ̀-ǹgbẹ̀ ti di kẹ-ẹrẹ, idi ti o ti ri bọ̀kẹ̀lẹ́ ti di pẹlẹbẹ, ori ti o ti ri kidiri ti di palaba, oju ti o ti gún rebete ti jin sinu wọ̀m̀wọ̀, ikùn ti o ti yọ bọmbọ ti di pẹlẹbẹ, bi o sọrọ ẹrin nwọn ko jẹ rẹrin, bi o ki wọn, nwọn ko jẹ dahun, bi o pade wọn lọna, ara l'o pade, ọkan ko si nibẹ, ẹmi wọn ti lọ si orişirişi ọna, bi nwọn si ti nronu ẹniti awọn o fun ni eyi, ti nwọn nronu ẹniti awọn o fun ni tọhun, bẽ nã ni nwọn nronu bi ori awọn yio ṣe takiti ni ọjọ ti a ba mu u kuro l'ọ́rùn awọn.

Bi ire bi ire, ọjọ nlọ. Lãrin ọjọ wọnyi, awọn ọmọde ilu bẹrẹsi ṣe ipade ni aṣĩri. Bi nwọn ba ti jade ninu ipade wọn, nwọn a pa ẹnu mọ́, ko si ẹniti o tun le mọ nkan ti nwọn sọ, ọmọ ko jẹ wi fun baba, aburo ko jẹ wi fun ẹgbọn, afi bi ẹni pe gbogbo wọn gbe ogun ti awọn àgbà ni.

Ọjọ mẹsan pe, gbogbo awọn ijoye jade pẹlu aṣọ olowo iyebiye, ọpọlọpọ ti kan posi, ọpọlọpọ ti gbẹ ilẹ oku, ọpọlọpọ ti ra adiẹ ìrànà, sibẹ, ọjọ nã ni ede yi to ye ni pe, ko si ẹniti ko mọ pe on o ku lọjọkan ninu awọn ọmọ enia, ṣugbọn ko si ẹniti o fẹ ki on mọ ọjọ iku on. Ẹniti o ba ri awọn ijoye nla wọnni ninu aṣọ nla, ibanujẹ nla ni oluwarẹ̀ ri, ẹniti o wo wọn wo ẹkún, o wo ọ̀ṣẹ́, o wo àròkàn ọkàn. Oju wọn ko dara.

Awọn ọmọde ilu ko fi ọrọ si ẹnu Adajọ Ole lati sọ, nwọn ko tilẹ gba a si ipade wọn. Igbati gbogbo enia de ọja, ti Adajọ Ole jade ninu ẹwu oye rẹ̀, ti awọn babalawo ati ọdẹ ti to yi awọn ti a da ọjọ ole fun tan, ni ẹniti awọn ọmọde fi ọrọ si lẹnu dide ti o bẹrẹ ọrọ o ni:

"Kabiyesi, k'ẽ gbo, k'ẽ tọ fun ni, ki ade pẹ lori, ki bata pẹ lẹsẹ, ẹ o ṣe ọba wa di alẹ, ọba ati ijoye ni gbongbo ilu, bi a ba bẹ́ gbongbo, a bẹ igi; bi a ba wu gbongbo, a wu igi; bi a ba fi iya jẹ gbongbo, a fi iya jẹ igi. Ko si odo ni ode aiye ti ko ni orisun, ko si ile ti ko ni ipilẹṣẹ. Bi ipilẹ ba jẹ okuta, dandan ni ki ile duro, bi ipilẹ ba jẹ yanrin, dandan ni ki ile wo. Ninu gbogbo ọga ti ọmọ enia ni laiye, ko si eyiti o ṣe alaibikita ti o dabi ofin. Ninu gbogbo eto ti ọmọ enia nṣe lode aiye, ko si eyiti ko nkãnu ẹnikẹni ti o dabi ofin. Kil'o nti ọmọ enia sinu ẹ̀wọ̀n? Mo ṣebi ofin ni, kil'o si nso ọmọ enia kọ lori igi? Mo ṣebi ofin nã ni.





"Gbogbo awọn ewe ilu Ifẹhinti ki yin. Nwọn ki yin, nwọn ki yin dãdã. Nwọn ni, ofin ilu Ifẹhinti, ọmọ ilu Ifẹhinti l'o ṣe e; eto ilu Ifẹhinti, ọwọ ọmọ ilu Ifẹhinti l'o wa. Nwọn ni awọn pa ofin ti o de gbogbo yin rẹ́ patapata titi aiye, ẹ ko ni ku iku kiku kan. Lati oni lọ, ẹnikan ko ni ba ẹnikan ku ni ilu Ifẹhinti mọ, ki olukuluku mã lọ si ọrun rẹ̀ wõrọ ni."

Nigbati ọkunrin yi pari ọrọ rẹ̀, omi bọ loju awọn ijoye wọnni fun ayọ pe awọn ọmọde ilu ṣe bẽ fẹran awọn, ṣugbọn sibẹ, nwọn kò fẹ ki ilu ti itori iku awọn yí ofin pada. Nwọn bẹ awọn ewe ki nwọn jẹki awọn ku ṣugbọn awọn ọmọde kọ jalẹ ko. Ibiti nwọn tilẹ ti nsọrọ le ori kiku tabi aiku ni olori wọn ti wi fun Adajọ Ole ki o paṣẹ ki nwọn gbe ìké igi ti nwọn iba gbe ọrun wọn lé bẹ́ lọ, ti o si tun le ẹniti o gbe ada ati ba fi pa wọn lọwọ jade ninu agbo. Igbati ọran si ti di bẽ ko si ohun ti ẹnikan le ṣe.

Nikẹhin ṣa awọn ijoye wọnyi gbagbe iku nwọn mura ati mã ba ile lọ. Àṣẹ́ bẽ ni aiye ko ṣẽ fi silẹ to! Ẹ wa w.. wọn bi nwọn ti nl.. Ete wọn ti gbẹ nibiti nwọn ti nronu, iṣan ọrùn wọn ti han gbangba nitori alai jẹun, oju ti di wọ̀n̄wọ̀ o ti sa wọ inu, ẹ̀rẹ̀kẹ́ di palaba nitori ebi, ẹsẹ gbẹ, ọwọ gbẹ, ọmọ ika gbogbo ri tĩnrin bi ara ekolo, àwọ̀ ara wọn ti hunjọ gbogbo, omiran dabi ẹniti ẹ̀gbẹ ikọ́ ti fẹrẹ pa ku, omiran dabi ẹniti o njiya lọwọ aisan oke ilẹ, ẹrẹkẹ ẹlomiran dede wu gelete kalẹ lasan, akoko yi ko dara ju bẽ lọ fun awọn ijoye ilu Ifẹhinti, iba ṣe pe Olodumare ko fi ero didun sinu awọn ọmọde ilu nã, nkan nã iba buru gidigidi.

Bayi ni aiye ri, ẹnyin enia wa. Nkan ti awọn ọmọ araiye ko ba fẹ ki a ṣe si awọn ni nwọn mã nṣe si n.., ẹ wo o, Ekeji Ilu ko bikita bi a pa ọmọ ọlọmọ tabi a ko pa .a, o ti onitọhun sinu ijangbọn. Ọba fẹ ki a pa Ekeji Ilu bẽni on pãpã ko fẹ lati fi aiye silẹ. Olukuluku awọn ijoye wọnni ti de ẹnu ibode iku ki nwọn to sa pada, ẹnikẹni ninu wọn ko fẹ lati ku, ṣugbọn iku ọmọnikeji ko jamọ nkankan.

Nwọn sa ṣe bayi nwọn bọ lọwọ iku. Bi a ba si ro o dãdã, a o ri i pe ẹniti nwọn fi iya jẹ ni Àdììtú-Olodumare nitori igbati ọba wi fun on ati baba rẹ̀ ki nwọn mã lọ, pọnun kan pere l'o fun u lati fi dipo iya ti o ti jẹ. Ko wa si pe nwọn nri

ọgẹdẹ bẹ́ bi ti atijọ mọ. Iba owo diẹ ti o ku lara owo ti nwọn ri pa lori igbin ti Àdììtú ti he lọjọ ti o kọ nbọ ni Ifẹhinti nikan l'o ku, o si ti fẹrẹ tan, ṣugbọn ki o to di pe ọran yi ṣẹlẹ bẽ ayipada rere ti bẹrẹsi de si Òbìrí-aiye. Ibiti o gbin agbado ti Àdììtú kọ mu wa si, jẹ ilẹ ọlọra, bẽni o tun ṣe oko iṣu kekere kan si eti oko agbado, ṣe ni iṣu bo ruru, ti ila inu oko yọ ewe gbẹ̀gẹ̀gbẹgẹ, ti ata so jìnwìnnì, ti ohun ọgbin gbogbo dabi ọgẹdẹ ti a gbin si eti ipa odo, ti nso eso rẹ̀ lakoko rẹ̀.

Bi a ba mu ata kuro, ko si nkan oko ti o ti imu eso wa ju bẽ lọ ṣugbọn bi nwọn ti ṣe dide fihan pe nwọn ko ni ṣai mu eso wa bi o ti yẹ. Bi o si tilẹ jẹ pe ipo ti oko Òbìrí wa ko ju bayi lọ, sibẹ, ko jẹki ete oke on duro lori ete isalẹ bẽ, ẹnu ni Òbìrí-aiye nfọn kiri. A ni igbati agbado on ba gbo, on o ta apakan on o jẹ apakan, ẹnikan ti o yaju si on nigbakan yio jiya nitori on o ri owo fi ba a ṣe ẹjọ, on o gbe e sọ si ẹwọn, owo ti on ba tun nri ni oko on, on o fi ra ẹṣin meji on o mã gun ọkan, iyawo on yio ma gun ekeji, Àdììtú ko gbọdọ gun nibẹ nitori ọmọde ni, ati bẹ̃ bẹ̃ lọ.

Nkankan ṣẹlẹ lọjọ kan, ara Ipọnjudiran ko le, Òbìrí-aiye ko si le lọ si oko fun odidi ọsẹ kan, ṣugbọn Diran gbadun ni ọsẹ keji, ọkọ rẹ̀ wa lọ si oko. Igbati o de ọhun, nkan ko dara, ẹranko ọ̀yà ti ko ẹgbẹ wa si oko nwọn ge gbogbo agbado lulẹ patapata, ko ku ẹyọ kan fun oloko. Awọn ẹranko ẹlẹdẹ inu igbo tun ja sinu oko iṣu nwọn fa ẹkàn iṣu tu, erin kọja lãrin oko o ja gbogbo ọwọ iṣu, afi bi ẹni pe nkan buburu gbogbo ṣe ipade pe ki awọn ba ti Òbìrí jẹ, ọjọ ti Òbìrí si tilẹ de oko yi, ila so jinwinni gbogbo, bi ọya, ati ẹlẹdẹ igbo, erin ati ẹfọn si ti ba nkan jẹ to wọnni nwọn ko fi ọwọ ba ila rara, nitoriti ila si ta ni ọdun nã, inu Obiri-aiye dun, o lọ sile. Ni ọjọ kẹta ti o wa mã de oko, agbọnrin ti de oko, ó ti ká gbogbo ila jẹ patapata, agbọnrin jẹ eso, o jẹ igi o jẹ gbogbo ewe ila porogodo. Òbìrí-aiye ati iyawo rẹ̀ tun pada si ibanujẹ.



## ÀDÌÌTÚ-OLODUMARE DI ERO INU IGBO

Ko si owo fifi jẹun mọ fun idile Obiri-aiye, owo ti nwọn gba ni ilu Ifẹhinti tan, ko si ibiti tọkọtaya yi le ki ọwọ bọ mọ, ọmọ kan ṣoṣo ti nwọn bi ko ri nkan jẹ, ko ri aṣọ wọ̀, ko le ba ẹgbẹ rẹ̀ lọ si ode, asẹhinwa asẹhinbọ, Àdììtú pinnu ati jade ni ilu Ilakọsẹ.

Lọsan ọjọ kan bayi, o ke si baba rẹ̀, o ni :

"Baba mi, mo dupẹ lọpọlọpọ fun bibi ti ẹ bi mi. Láì ṣe aniani, bi o ba jẹ bayi ni ẹ wa tẹlẹ, ẹ ko ba ti ni ero pe ki ẹ bi mi, ẹ ko ba tilẹ le to ẹniti nni obinrin. Ṣugbọn, ayipada ti de. O di owurọ àná ti mo ti fi ẹnu mi ba onjẹ mọ, ṣugbọn nko ri ki ẹnyin pãpã jẹun, nko si ri ki iya mi bu okẹle. Nitorina, mo fẹ lati jade kuro ni ãrin ilu, ki nfi ori le ibikibi ti mo ba ri, bọya bi emi ba lọ, ẹnyin ati iya mi le ri ọna ati mã tọju ara yin. O digba o, baba mi, bi Ọlọrun ba wipe mo tun mã ri yin, a jẹ pe ng o ri yin, ṣugbọn bi Ẹlẹda ba pe oni ni àrímọ, a o mã pade ni ode ọrun."

Baba Àdììtú fesi si ọrọ yi, o ni, "Ọmọ mi, Àdììtú, nibo l'o mọ ti o ó ba lọ? A ko ni ará ile kan ni idalẹ ti o jẹ olowo ti o le tọ lọ, a ko ni iyekan kan ti o ṣe pataki ti o le lọ joko tì. Bi iya rẹ ba lọ gbọ nkan ti o wi, ó mã ku si ọ l'ọrun ni, nitori, lõtọ, a ko l'owo, ṣugbọn a ni ọ. Iwọ ni owo wa, iwọ ni oko wa, iwọ ni ile wa, iwọ yi nikan ju gbogbo ohun alumọni ẹlomiran lọ. Emi pãpã ti npa ero ati pada lọ si ilu Ifẹhinti, bọya mo le ri owo ya ki a fi mã jẹun, jọwọ, joko, ọmọ mi."

Ṣugbọn Àdììtú ti pinnu lọkan rẹ̀ pe on nilati lọ dandan. Ko wi nkankan fun iya rẹ̀.. Lọna kini, iya rẹ̀ yara bọ si ode nigbati o fi nsọrọ fun baba rẹ̀. Lọna keji, ko tilẹ fẹ sọ fun u, o ni, bi on ba jẹki iya on gbọ, yio di mọ on ni, ẹkun ni yio si mã sun nitori obinrin a mã fi omi oju ba ọrọ pataki jẹ.

Igbati baba rẹ̀ ri i pe ko gbọ, o fun u ni ada kan, o fun u ni ṣile kan-abọ, o ki i pe o digbõṣe, o si sure fun u o wọle o bẹrẹsi da omi loju pẹ̀rẹ̀pẹ̀rẹ̀, Àdììtú ba jade, o lọ si oja, o ra

ìwọ̀ apẹja, o ra iyọ pupọ, o si ra ịṣana to ile mẹfa dãdã. Ati ọja l'o ti ki ori bọ inu igbo ti o nlọ ni on nikan, pẹlu ebi ninu, láì si tilẹ mọ opin irinajo on.

Igbati o rin to wakati meji, o ja si oju ọna oko kan. Ọ ri ọgẹdẹ pupa meji ni ilẹ ti nwọn tobi dãdã. Ewe bò wọn lori. Ẹnikan ti nti oko bọ̀ l'o sọkalẹ nibẹ ti o tu ẹrù rẹ̀, igbati o tun mã gbe ẹrù ni ko ri awọn ọgẹdẹ nã nitori ewe bo wọn lori. Àdììtú kó mejeji, o jẹ ọkan lọjọ nã, o fi ekeji pamọ.

Igbati o tun ti kuro loju ọna yi nã ni o tun ti ki ori bọ inu igbo, ti o nlọ. O rin titi ilẹ fi ṣu lọjọ nã, igbati ilẹ ṣu patapata, o duro, o wa igọ̀ igi kan, o sun sibẹ.

Lọjọ keji o fi ori le inu igbo o nba irin rẹ̀ lọ, o jẹ ọgẹdẹ kan ti o kù, ṣugbọn, o jẹ ọgẹdẹ yi ko pẹ ti o de idi igi òro kan ti o ri ọpọlọpọ eso ti o wọ silẹ. O ko diẹ ninu awọn òro wọnyi on l'o si njẹ titi ilẹ tun fi nṣu lọ. Ni akoko yi, ó wà ni ãrin inu aginju gãn ni, ko si ọmọ enia ti o de ibẹ ri, gbogbo agbegbe jẹ igi àti itakun, o kun fun agbe ati aluko, aparo ati adaba, ekute ati ọkẹrẹ, ẹranko nla ati kekere, gbogbo agbegbe dudu kìjankìjan, ati ri oju ọrun ṣoro, igbo nã pọ gidigidi. Àdììtú-Olodumare tun sùn si igọ igi kan nigbati ilẹ ṣu.

Lọjọ kẹta wayi o, o pinnu ati wa ibikan ti yio fi ṣe ibugbe lãrin igbo nla yi. O rin titi, o de ibi odo kan bayi ti nṣan lati ori apata. Apa oke odo yi, ki o to di pe enia de odo gãn jẹ ilẹ titẹju, ibi yi ni Àdììtú wa aye si ti o fi ṣe ibugbe.

Nisisiyi o sọ ara rẹ̀ di ero inu igbo, o sọ ireti ati lọ si ãrin ilu nù, ijó ãrin ilu kò jẹ nkan fun u, ìlù ãrin ilu kò ni ipo lọkan rẹ̀, o di alabagbe ọbọ ori igi, alajọrin ejo ninu igbo, ọrẹ Adaba ati Oriri. Kini kan ni, ọkan Àdììtú ko bajẹ mọ, kaka bẽ, o wọ inu igbo o bẹrẹsi dẹ ẹ̀bìtì kiri, o dẹ mẹfa dãdã ki ilẹ to ṣu. Igbati ilẹ ọjọ keji mọ, ẹ̀bìtì mẹta ti pa ekute mẹta. Awọn ekute wọnyi ni Àdììtú fi ṣe onjẹ ãrọ. O mu ekute kuro, o tun ẹ̀bìtì dẹ, on nã tun lọ, o dẹ ẹ̀bìtì mẹfa si i, ẹ̀biti wa di mejila. Igbati o lọ wo awọn wọnyi ni irọlẹ, mẹrin ti re, nwọn pa ọkẹrẹ kõkan.

Bayi ṣa ni Àdììtú bẹrẹsi bá igbesi aiye rẹ̀ lọ ti o npa ekute pa ọkẹrẹ ninu igbo kiri.





Ọjọ keji ti o de ibudo rẹ̀ yi l'o mọ pe inu ijamba patapata ni on wa. O di ọsan ọjọ nã ni, l'o ba dede gbọ ti kiniun kan nbu ni apa iwaju rẹ̀ ti ọkan tun nbu lẹhin ti o si dabi ẹni pe bi nwọn ti nbu ni nwọn tubọ nsunmọ ara wọn.

Àdììtú-Olodumare gun ori igi lọ, o dakẹ nigínnigín nireti pe on o ri ki kiniun kan kọja, ṣugbọn dipo kiniun, ẹkùn l'o ri, ẹkùn rin siwa o rin sẹhin o ba ti ara rẹ̀ lọ.

Ibiti o wa yi jẹ ibiti o ti le ri inu omi kedere, igbati o kọ wo inu omi, o ri ogunlọgọ awọn ẹja, igbati o wo o lẽkeji o ri ọkẹ aimoye awọn ọ̀nì ti nwọn nrin kiri ninu omi, oniruru ni gbogbo wọn. Ẹnu omiran gun, o ri ṣọṣoro, ti omiran kò gun tobẽ ṣugbọn gbogbo wọn ni nwọn ni ehin ti o nipọn ti o mu bérébéré bi abẹ, gbogbo wọn ni nwọn si nwa si oke omi ti nwọn ngbe imu soke, ti nwọn nla ẹnu ha-nha.

Àdììtú joko si ori igi titi ilẹ fi ṣu. Igbati ilẹ ṣu, o sọkalẹ, o jẹ ọkẹrẹ diẹ o si jẹ igbin ti o ri he. O jẹun tan, o mu omi, o mu omi tan, o fi ẹhin lelẹ, o pa oju de, orun mu u lọ.

Ki o to ji ni ijọ keji, õrun ti ta. Ko ba tilẹ ti iji bi ko ṣe nkankan ti o dede duro si igba-aiya rẹ̀ teleku, o wuwo rinrin. Igbati Àdììtú la oju bayi, kil'o ma ri? Ejo l'o ka jọ si igba aiya rẹ̀, erè si ni. Orun ti Àdììtú sun wọ ọ lara pupọ, gbogbo wahala ti o si ti nṣe mu ki o rẹ ẹ pupọ, ko pa ara da rara, ere ṣe bi oku igi ni. Igbati o si fà ti ó ká jọ le e ni igba aiya ti ara rẹ̀ gbona mọ ọ dãdã, o kuku tubọ rọra joko ni tirẹ̀ ni. Ki iṣe gbogbo ejo nã ni igba aiya Àdììtú gbà, apakan ara rẹ̀ wà ni ilẹ. Igbati o ji ti o ri ejo yi, ko mọ ohun ti on le ṣe, ejo ka bi okiti ọ̀gán si igba aiya, o yọ ori jade, o nwo gbogbo agbegbe, bẽ l'ó nyọ ahọn lẹnu béré. Àdììtú rọra mu ara duro nigínnigín nireti pe igbati o ba ṣe diẹ ejo yi yio lọ, ṣugbọn kaka ki o san lara iya ajẹ, o nfi ọmọ rẹ̀ bi obinrin, ẹiyẹ nyi lu ẹiyẹ. Dipo ki ejo lọ, ṣe l'o tubọ nka iru rẹ̀ ti o ṣan silẹ le ori igba aiya Àdììtú, ti ẹrù wọ on mọlẹ tintin.

Igbati o ṣe, ara Àdììtú kò gba a mọ, ẹrù erè yi mã pa a ku, o ba pinnu lati parada. Ẹ̃kan wùyà ti o dide, ejo tuka o bẹrẹsi wọ́ ni ilẹ kiri. Riri ti o ri Àdììtú, ó gbera kuro ni ilẹ o na ọrun siwaju bi ẹni ki o fi ori sọ ọ ni igba aiya, ṣugbọn onitọhun yẹ̀ ẹ́, ilẹ l'o ba ori lọ. Ejo yi wa tun nfẹ lọ́ mọ́ ọ lara, ki o lọ́ mọ́ ọ

tan ki ó wa tú ara rẹ̀ lẹ̃kan ṣoṣo ki ó dá a lẹhin, ṣugbọn Àdììtú ko jẹki eyi ṣẽ ṣe, bi o ti nlọ́ mọ ọ l'ẹsẹ ni o ngba ẹsẹ rẹ̀, igbati o ṣe, o ri aye lọ́ mọ Àdììtú ni ibi idi, Àdììtú ba ogedengbe lọ silẹ, awọn mejeji wa jọ nyi kiri, bi o ba yi le ejo lori, ejo nã a yi le e, bi ejo yí le e on a tun yi le ejo pada, gbogbo ara Àdììtú-Olodumare kun fun àbàtà pálapàla.

Ki Àdììtú to sun lalẹ o ti pọ́n ada rẹ̀, o mu bi abẹ, o ri ada nã mọlẹ ó kọ oju rẹ̀ ti o pọn si ita. Ero rẹ̀ ni pe a ki i mọ bi on ba sunlọ tan ejo le wa wọ́ ba on, bi eleyi ba si lọ ri bẽ, o nireti pe ada on yio ge e. O ri ada nã mọlẹ lọna ti o jẹ pe ẹhin ada nã ko le wọlẹ ju bẽ lọ bi o ti wu ti nkan nã wuwo ni oju ada ti o wa loke to. Ibiti erè yi gba gun Àdììtú laiya ki iṣe ibiti oju ada yi wa.

Ija on ati ejo wa tubọ nle igbati o si di pe ejo mã pa a, o ranti pe on ti ri ada mọlẹ, o ba dọbalẹ le ejo nla nã, o fi gbogbo ọwọ di ọrùn rẹ̀ mu, o di i mu, o ho mọ ọ dãdã, ejo wa nwọ rẹ̀rẹ̀, o ngbe e kiri. Igbati o ṣe, Àdììtú wa ọgbọn, o kọ oju ejo si ibiti ada rẹ̀ wà, ṣugbọn nigbati o ku diẹ ki ejo de ibiti ada wa, ó lọ́ ori, ó yán Àdììtú kuro lẹhin rẹ̀, diẹ l'o si ku ki o bọ si ẹnu ada on pãpã, ṣugbọn di dide ti o dide, ṣe l'o ki ọwọ bọ ẹnu ejo ti o fa agbọn isalẹ ati ete oke, ti o fẹ oju ejo toto, yiyi ti ejo si ni ki on yi pada lọwọ rẹ̀, ẹnu ada ni ejo gbe ọrun le, Àdììtú ba fi gbogbo agbara tẹ ọrun rẹ̀ mọ ọ, ada ge e wọle dãdã.

Igbati Àdììtú ti ṣe eyi ni on nã ti mọ pe on fa ijangbọn l'ẹsẹ, o sare tagbaratagbara, igbati ejo ko si ri ẹniti on nba ja mọ, ṣe l'o bẹrẹsi fi ori gbe ilẹ kiri. Bi o gbe e bọ abẹ ìtí, a gbe e bọ abẹ ìràwé, bi o gbe e le okuta a gbe e le kukute, igbati o pẹ, ó kó wọ inu omi lọ, oju omi gbogbo pupa lọ ṣũ.

Erè ko mu ọran nã jẹ, nitori nigbati o to ọjọ marun, a ri i o fo loju omi, o ti ku patapata.

Ṣugbọn bi ẹni pe ọjọ ijangbọn ni ọjọ nã jẹ fun Àdììtú ni. Igbati o simi ija on ati erè tan o lọ wo awọn ẹbiti rẹ̀. Mẹfa pa ekute ti o tobi. O ti hun ìyànmọ́ kan fun ẹja pipa, igbati o si mã de ibi ìyànmọ́ yi, dipo ẹja, ejo l'o pa, jomijoke ni. Igbati oníyànmọ́ ri ejo ninù iyànmọ́ rẹ̀ ṣe l'o ju ìyànmọ́ si omi pada, Àdììtú ko de ibi iyanmọ mọ.





O ba pinnu lati dẹ iwọ rẹ̀ ki o pa ẹja, o wa igi tutu ti o tobi diẹ bayi, o so okun iwọ rẹ̀ mọ ọ. Ko pẹ ti o ju iwọ rẹ̀ sinu odo ti o pa ẹja àrọ̀ titobi kan. O yọ iwọ lẹnu eyini, o ju u si okiti o tun dẹ iwọ rẹ̀. Láì pẹ o pa ẹja ọsàn nla kan. Lẹhin eyi, o wa dide, o lọ si ori okuta kan ti o yọ téńté lãrin ibu omi. Okuta ti o yọ ori soke diẹ diẹ wà gbogbo ti enia le tọ̀ ki o to de ori okuta yi, awọn ni on nã lò de ibẹ. O ba fi iwọ rẹ̀ si omi, bi o ti joko le okuta ti o na ẹsẹ siwaju, ti diẹ ninu atẹlẹsẹ rẹ̀ wà ninu omi, afi igbati o wo kini kan ti o nbọ sì-ì si ibi ẹsẹ rẹ̀. Were o fa ẹsẹ si oke, ọ̀nì ni. Ṣugbọn, sibẹ, ọ̀ní tun ngbe ẹnu bọ ha-nha, Àdììtú ba ju idi ọpa ìwọ̀ rẹ̀ si i lẹnu. Ọni pa ẹnu de mọ ọ, gbogbo ehin ọni wọle si ọpa ìwọ̀ lara ko ṣẽ fa yọ mọ, o wa di pe ọni ngbe ìwọ̀ lọ. On fa ọpa ìwọ̀ lori okuta ọni fa a ninu odo, ijangbọn de. Bi ó ba tilẹ fa ọni gun ori okuta kil'o fi mã pa a? Ibikibi ti Àdììtú-Olodumare ba nlọ ninu igbo, ada rẹ kì íyà á, nitori o ti so okun agba ti o yi kan mọ ẽku ada rẹ̀, ṣe l'ó si mã ngbe e kọ ejika kiri. Ṣugbọn nigbati ọran ti ọni yi kọ de o gbagbe pe ada wà ni ejika on, igbati o ṣe ti o wa ranti o pinnu ati bẹ́ sinu odo ki o lọ ba ẹranko buruku nã ja. Were o fo sinu omi on ati ọni fi ija pa ẽta. Igi ti o wa lẹnu ọni ti ko le fa ehin rẹ̀ yọ lara rẹ̀ jẹ iranlọwọ pataki fun Àdììtú, o wa ku ibiti o le fi ada ṣa lara ọni ti gbogbo ẹhin rẹ̀ dabi okuta. Bi ọni ti nju iru ni o nyẹ̀ ẹ ko gbọdọ jẹki o kan on ki o má ba ge e lara. Ija nla wa ṣẹlẹ ninu ibu omi nla yi, ẹja salọ nwọn sa pamọ bẹ́rẹ̀bẹ́rẹ́, awọn jomijoke gbogbo sa kuro ninu odo, bi Àdììtú ti nmu ori ọni ni ọni nyọ́ bọ́rọ́, bi o ti nwa igba aiya rẹ̀ ni oni nyẹ̀ ẹ́ gẹ̀rẹ̀, omi ti o ti tòrò gbogbo di wiwu, igbati ọni si wa fa ehin yọ lara igi, Àdììtú kan ijangbọn, bi o ba mõkun lọ si isalẹ, ọni a mõkun ti i, bi o wa sokẹ ọni a tẹle e, asẹhinwa asẹhinbọ, sisa ni Àdììtú sa jade ninu omi—tani njẹun ti aja nju iru!

Lẹhin eleyi, ko si nkankan pataki ti o tun ṣẹlẹ si Àdììtú lọjọ yi, ṣugbọn awọn ẹranko buruku gbogbo ko ye mã kọja, oniruru ejo nwọ lulẹ lati ori itakun, bẽni awọn kiniun nke si ara wọn l'origun mẹrẹrin ibudo. Sibẹ, Àdììtú ko wipe on mã lọ.

Lati ọjọ keji eyi l'o ti bẹrẹsi okùn dídẹ lati mã fi pa ẹranko. O wa ọna titi, o ri ibiti iho ọkan ninu awọn kiniun wa o si

pinnu lati ba a ṣe ọrẹ. Ni ọjọ ti o kọ bẹrẹ ọrẹ yi, agbọnrin ti okun rẹ̀ pa l'o fi bẹrẹ. Adiitu kun agbọnrin ó ko itan meji o di oju ọna iho kiniun ni akoko ebi gãn ti kiniun nbọ kikankikan. Bi Àdììtú ti mã de ẹnu iho ni kiniun jade, riri ti o si ri i ṣe l'o nbọ gãnran lati ba pa a jẹ, ṣugbọn ki o to kan a lara onitọhun ti ju itan agbọnrin kan si i, kiniun bẹrẹsi jẹ eleyi, ki o si to wa tun pari eyini, o ju itan keji. Ibiti kiniun ti njẹ ẹ lọwọ, Àdììtú lọ.

Ibiti Ọlọrun tun ti mã ran Àdììtú lọwọ, o dede ri ẹ̀wọ̀n nla kan he nibiti o gbe ndẹ inu igbo kiri, o ba lọ dẹ ẹwọn yi si oju ọna iho kiniun tobẽ̀ ti o jẹ pe bi kiniun ba ni ki on jade ṣe ni ẹwọn yio wọ́ mọ ọ l'ọrun ti ko ni le kuro loju kan. Àdììtú so ẹwọn yi mọ igi rabata kan ni ẹba iho ẹranko nã. Igbati kiniun ni ki on jade, ṣe ni ẹwọn wọ́ mọ ọ lọrun ti ko le lọ mọ. O ja titi, ko ṣẽ ṣe. Ibẹ nikan ni o wa, ati jẹun si di iṣoro gidigidi. Ibi yi l'o ti wa mọ oju Àdììtú dãdã, nitori on l'ó nbọ́ ọ. Igbati o ba ti to akoko ati jẹun, a gbe onjẹ wa. Bi ire bi ire nwọn ndi ọrẹ, o di ki o mã fi ọwọ pa kiniun lara, nwọn jọ nṣire. Igbati o mã to oṣu meji, nwọn ti di ọrẹ patapata. Lẹhin eyi, o tu ẹwọn kuro lara igi, o nmu ẹwọn lọwọ, kiniun ntẹle e bi aja kiri. O kọ kiniun nã dãdã. Bi o ba ti gbọ súẹ́ nibikan ti o wo kiniun loju ti o na ika sibẹ were ki kiniun bẹ́ ki o pa nkan nã wa ni.

Bayi ni Àdììtú bẹrẹsi ṣe si ẹranko gbogbo. Ó bá inaki nla kan mu ọrẹ ko si si ohun ti on ko le wú kuro ni ilẹ tan. O le gbe okuta titobi, o le fa igi nla tu, iyatọ diẹ l'o si wa lãrin on ati enia afi ti irun ti o bo o lara bi aṣọ. Àdììtú pãpã fẹrẹ di ọ̀bọ, nitori ṣe ni on ati awọn ọ̀bọ jọ mã nfo lati ori igi de ori igi. Nwọn ti mọ oju rẹ̀ pupọ, nwọn ti sọ ọ di ekeji awọn. A tilẹ mã se ase fun awọn ẹranko. Ni agogo mẹta mẹta l'o mã npade awọn agbọnrin kan bayi. A ti gbe onjẹ si ita ibudo rẹ̀ fun wọn. Awọn nã ki isi ṣai wã ma jẹ onjẹ agogo mẹta yi.

Àdììtú gbe ọdun meje bamubamu ninu igbo ki o to fi oju ba ẹniti o jẹ enia rara. On de ibẹ nigbati o di ọmọ ọdun mẹrindilogun gẽre, igbati o si fi mã ri ẹnikẹni o ti di ọmọ ọdun mẹtalelogun dãdã. Ko si ẹniti o le ri on pãpã ki o pe e ni enia mọ, irun gbogbo ti kun bo o loju, rungbọn ti yọ ṣọbọlọ, oju on pãpã ko yatọ si oju aṣiwere mọ.

Ṣugbọn ko si aṣĩri inu igbo ti o jẹ ipamọ fun u. Ni ọjọ kan kiniun rẹ̀ mu u lọ si ibikan bayi, igbati o de ibẹ ehin erin ti o ba ju ẹgbãji dãdã. O ba mu ọkan nibẹ o nfi tilẹ kiri. Fun odidi ọdun mẹta Àdììtú ko mọ̀ ju pe ki on sun ẹran tabi ẹja jẹ lọ, bi o ba ri igbin ki o sun igbin jẹ, bi o ri ijapa ki o sun ijapa jẹ. Ko si àwo ati se ọbẹ̀ rara.

Ni ọjọ kan, Àdììtú pinnu ati mọ ikoko, igbati o pẹ ti o ti nyi inu igbo kiri, o kan amọ̀.

O wa amọ diẹ o di ori okuta ti o tẹju pẹrẹsẹ kan. Àdììtú de ori okuta yi o da amọ le e, o wa okuta kan ti ko ju ọmọ ọlọ ata lọ o bẹrẹsi fi gun u, o gun u titi, o gun u to wakati mẹfa dãdã ki o to di pe amọ yi to ati fi mọ ohun ti o jọ ikoko rara. Igbati o sa ṣe, o ṣe ikoko kan ti o nipọn, ṣugbọn odidi ọjọ kan l'o tun fi da ina le ikoko lori ki o to di pe o le fi se nkan.

Ni ọjọ ti Àdììtú jẹ ọbẹ̀ ti o fi àwo rẹ̀ yi sè tan, nkankan ṣẹlẹ si i. Lati ọjọ ti o ti de inu igbo, ile iṣana kan l'o ti nlo nitori ki isaba ṣana, ina ti o ba wa ni ilẹ ni o mã nfi da omiran, yio ko igi si i ṣa ni. Lọjọ yi, o ko gbogbo ile iṣana rẹ̀ ti o ku jade lati inu iho okuta ti o ti mã nfi wọn pamọ si, o ko wọn le ilẹ ni ita ibudo rẹ̀, o ṣe bẽ o sunlọ, igbati o ji ti o lọ wo awọn okùn ati ẹ̀bìtì rẹ̀ ko palẹmọ, o kanju bọ sinu igbo pe on ti pẹ ki on to ji. Ki Àdììtú to wo awọn nkan ti o dẹ wọnyi tan ojo nla bẹrẹsi rọ̀, igbati o si fi mã de ibudo, agbara ojo ti gba gbogbo iṣana lọ patapata.

Àdììtú-Olodumare wo oke lẽkini, o wo o lẽkeji, o tun wo o lẽkẹta omi bọ loju rẹ̀ o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni :

> Ha ! Ẹlẹda mi, temi ti jẹ ?
> Olodumare, temi ti jẹ ?
> Ọlọjọ Oni, temi ti jẹ ?
> Temi ti jẹ lãrin ọmọ enia ?
> Baba mi wá onjẹ, ko ri jẹ
> Iya mi wá onjẹ, ko ri jẹ
> Mo t'ori bọ 'gbo nitori ati jẹ
> Mo di ẹgbẹ akata tori ati jẹ
> Alabagbe kiniun, tori ati jẹ

Ekeji imado tori ati jẹ
Ọnakọna ti ng o ba gba loni,
Iwọ Ẹlẹda mi, má ṣai kọ mi.

Igbati Àdìitú sọ bayi tan, o bẹrẹsi wa gbogbo agbegbe kiri, igbati o pẹ ti o si ti nwa ibẹ ka, ṣe l'o dede ri ile iṣana kan ti on ti ta sinu akisa yipo loju omi ṣugbọn omi ko tilẹ de ibiti ile iṣana yi wa rara. Iyalẹnu ni eleyi jẹ fun u. Ko ye e bi o ti ṣe lọ dá ọkan ninu awọn ile iṣana wọnni dì sinu aṣọ rara, bẹ̃ni ọjọ pẹ ti o ti ta a sinu aṣọ bẹ̃.

Igbati o ṣe, Àdìitú kó kuro ninu ibudo o fi ori le apa ọtun rẹ̀, o nlọ, o nlọ ṣa, ko ya si ọtun ko ya si osi mọ, o nireti lọkan rẹ̀ pe, igbati o ba pẹ ṣa, on o kan ibiti ọmọ enia ngbe on o tilẹ le wadi diẹ nipa awọn obi on.

Lõtọ, igbati o rin irin ọjọ meji gbako, o ja si ilu kan bayi ti orukọ rẹ̀ njẹ Ajédùbúlẹ̀. Ni akoko yi, o ṣoro ki enia to le ri Àdìitú ki o sọrọ si i. Fun odidi ọdun meje ko ge irun ori, rungbọn rẹ̀ ti o si bẹrẹsi hu ninu igbo ti hu yáwiri nitori on nã ti di ọkunrin. Ko si pe o fi ọṣẹ wẹ̀, fun odidi ọdun meje nã, ewe l'o fi ngbo ara ninu omi, aṣọ kan ṣoṣo l'o ni lara, on nã si ni ẹwu ati ṣokoto pe-npe ti o ti fi nlọ si ile iwe ri, eleyi si ti wa ya to bẹ̃ ti ẹwu ti kuro ni ẹwu ti ṣokoto kuro ni ṣokoto ti gbogbo aṣọ dabi jọ̀wọ̀lọ̀ ọgẹdẹ lara. Gbogbo ara dudu fafa, irun ori ri gẹlẹti, ẽkan ọwọ ati ẹsẹ yọ ṣọbọlọ, rungbọn hu yawiri, irawe ati ẹrun igi ati oniruru ẽra gba gbogbo ori kankan.

Igbati o kọ wọ ãrin ilu, wèrè ni gbogbo enia pe e, ṣugbọn ehin erin ti o fi nti ilẹ l'ó wọ onisowo kan loju ti o ba lọ sọrọ si i. Oniṣowo yi ki i, on nã dahun dãdã, o bẽre ki o jẹki on yẹ ehin erin ọwọ rẹ̀ wo, on nã fun u l'aye. Bi o ti yẹ ẹ wo tan l'o ni on fẹ ra a, Àdìitú ti ko tilẹ ni kọbọ lọwọ gba fun u, ṣugbọn igbati oniṣowo sọ pe on o san pọnun mẹwa, ti Àdìitú-Olodumare fẹ dahun pe pọnun mẹwa pọ ju ni ti on ṣe ni oniṣowo keji ti o ti ngbọ ohun ti nwọn nsọ ka pọnun mẽdọgbọn le Àdìitú lọwọ.

Àdìitú sa gba owo. Ohun ti o kọ ṣe ni ki o lọ si ọdọ ẹniti nta ọkà ki ó dá ọka jẹ, ekirí ẹran mẹfa bamubamu ni o ra fi ba okele lọ si apoluku. Lẹhin eyi, o wẹ, o tun ara ṣe, o ra buba kan, ṣokoto kan o si tun ra fila kan. Nwọn da awọn wọnyi tà ni, ki iṣe pe nwọn fi wọn ọ da, ṣugbọn, sibẹ nã, igbati o wọ aṣọ wọnyi nwọn ba a mu to. Eleyi san ju akisa bĩ jọwọlọ ọgẹdẹ ti o ti nko bora kiri. O gbe ori rẹ̀ fuń ẹniti nge irun, nwọn ba a ṣe e dãdã, o mu abẹ mimu o fi fa rungbọn. Bi enia ba wo o bayi, afi bi ẹni pe ki itun ṣe on ni mọ. Tẹlẹtẹlẹ, Àdìitú dara l'ọmọkunrin, afi bi a ba mã tan ara ẹni jẹ. Bi ilu rẹ̀, Ilakọsẹ, ti kere to, ti awọn enia ibẹ si buru to, oju awọn ọmọbinrin ibẹ ki ikuro lara ọkunrin yi, Àdìitú-Olodumare, ẹni Ọlọrun da ko ṣẽ fi ara wé.

Igbati o ti wá ile kan hãya ti o duro fun bi ọjọ mẹta ní Ajédùbúlẹ̀ ni o ti pada sinu igbo ti o wa ehin erin lọ.

O pẹ diẹ ki o to ri ibiti awọn ehin erin wọnyi wa, nitori igbati o ti ku bi wakati kan-abọ ki kiniun ti o mã ntẹle e bi aja de Ajédùbúlẹ̀ ni ọjọ ti o kọ wa si ilu nã, ni ọdẹ kan ti ri i ti o pa a. Sibẹ ṣa, o de ibiti ehin erin wọnyi wa dandan. Ko si ilu nã ni ode aiye ti ehin erin ti tà bi Ajédùbúlẹ̀. Ibiti Àdìitú sa ti di olowo ni yi, ṣe l'ó nlọ sinu igbo ti o nlọ pẹlu ẹrù ehin erin, igbati o fi mã to oṣu meji, Àdìitú-Olodumare ti ni to ogun apo owo dãdã.

Ko pẹ lẹhin eyi ti o ra ilẹ ile lọwọ ọkunrin olowo kan. Owo ọkunrin nã pọ gidigidi, bi o si tilẹ jẹ pe igbati opin ọdun kan fi mã pari, Àdìitú ti ni to ọgọrun apo owo dãdã, sibẹ owo rẹ̀ yi ko to nkan rara lara ti ẹniti o ta ilẹ ile fun u. Ibi ilẹ títà yi sa ni on ati ọkunrin nã ti di ọrẹ patapata. Ọrẹ wọn jinlẹ gidigidi. Igbati Àdìitú-Olodumare pari ile rẹ̀ ti o nkọ tan bi ile nã ni ọkunrin yi ngbe bi tirẹ̀ ni, ko si ẹniti o mọ. Ọmọ l'o fi Àdìitú ṣe, ọmọ kanṣoṣo ti on pãpã ní, obinrin ni.

Àdìitú ko gbe ju ọdun mẹrin ni Ajédùbúlẹ̀ nigbati ọkunrin olowo ti o fẹran rẹ̀ yi ku, ko si ju oṣu mẹfa ti ọmọ rẹ̀ kanṣoṣo ti o ni wọle ọkọ nigbati iku de ba a yi.

Igbati nwọn mã ka iwe akọsilẹ fun pipin ohun ini ọkunrin yi ohun ti nwọn ba ni eyi :

"Eleyi ni majẹmu ikẹhin ti mo ba awọn ti yio pin ogun mi da lẹhin ti mo ba fi aiye silẹ. Emi, Ìtùnú-aiye Aiyedẹ̀mí, Ogo Oluwa, kọ eyi silẹ lori ohun ini mi, loni, ọjọ kẹtalã oṣu kẹjọ, Ẹdẹgbẹwa Ọdun o le mejidilọgọta lẹhin iku Oluwa wa, mo

si yan awọn meji yi, Õtọkorò ati Èkéṣubú ní awọn ti yio pin nkan mi gẹgẹ bi eto yi :

'Mo fi ẽdẹgbẹta apo owo fun iyawo mi, Ifarada, Ogo-Oluwa, ki o mã lo eyini titi ọjọ iku rẹ, mo si fi ile mi ti a jọ ngbe fun u, on nã ni ki o ni owo ti awọn ti o hãya iyãra ninu ile nã ba nsan titi lailai.

'Mo fi ẹgbẹrun apo owo fun ọmọ mi obinrin ni ireti pe on ati ọkọ rẹ yio mã fi ṣowo. Mo fi ilẹ mi ti nwọn ti nwa epo mọto fun u pẹlu. Mo fi gbogbo kòkó mi fun u, mo fun ọmọ mi obinrin yi, Àbẹgbé ni pẹtẽsi mẹrinlelogun ninu awọn ile mi ni Ajédùbúlẹ̀ mo si fun u ni mọto ayọkẹlẹ mẹfa ati mọto ẹlẹ́rù mẹfa pẹlu. Eyiti o ba wu ù ninu awọn ile mi ati ninu awọn mọto mi ni ki o kọ mu ki nwọn to mã fi iyoku fun awọn ti mo pin wọn fun. Ọmọ mi, Abẹgbe yi ní ifẹ mi gidigidi, mo si fẹ ki aiye on ati ọkọ rẹ dara.

'Mo fi ẽdẹgbẹta apo owo fun Àdìitú-Olodumare ti mo ti gba ṣe ọmọ, mo si fun u ni ilẹ mi ti nwọn ti nwa gõlu ati gbogbo oko rọ̀bà mi. Ki o mu ile mejilã ati mọto ayọkẹlẹ mejilã pẹlu mọto ẹlẹ́rù mẹfa lẹhin ti ọmọ mi, Àbẹ̀gbé, ba ti mu eyiti o wu u tan. Ṣugbọn ki Àdìitú-Olodumare to le jẹ anfani wọnyi ó ni lati fi ọwọ si iwe pẹlu awọn ti yio pin ogun mi pe iyawo ti on ó kọ fẹ nilati jẹ ọmọ Ajédùbúlẹ̀, ki o si to le fẹ omiran tẹle e, o nilati to ọdun mẹwa gbako ti o ti fẹ ẹ.

'Mo fi ile meji meji silẹ fun ẹni kõkan ninu awọn aburo mi obinrin mẹfẹfa.

'Ki awọn ti mo fi si itọju ogun pinpin yi pin ohun ini mi miran ti nko iti idarukọ lọna ti o ba wù wọn.

'Ẹnikõkan ninu awọn ti mo fi si itọju ogún pipin yi nilati mã gba apo owo kõkan lọdọ̃dun fun iṣẹ wọn. A nilati mã yọ eleyi ni ibẹrẹ ọdun ninu awọn ohun ini mi.

'Fifi Ọwọ si iwe :

1. Oninkan : Ìtùnú-aiye, Aiyedẹ̀mí, Ogo-Oluwa.
2. Ẹlẹri : Ilọri Ẹ̀tọ́-aiye.
3. Ẹlẹri : Àjàlá Olododo.
4. Agbẹjọ́rò ti o kọ eto yi silẹ : Òyé-pọ̀, Ọgbọ́n dìran.'"





Bayi ni akọsilẹ ti ọkunrin olowo yi kọ. Igbati o nkọ ọ, ko mọ pe on ó tete kú, ṣugbọn ko pẹ ju bẽ lọ ti o kọ ọ, ti ẹlẹmi gba a.

Akọsilẹ yi sọ Àdìitú di olowo tabua ni ọjọ kan ṣoṣo. Nkan ti ẹniti o ni awọn ohun ini wọnyi sọ pe ki Àdìitú ṣe ki o to mã kó gbogbo nkan rẹ ko ju pe ki o fi ọwọ si iwe pẹlu awọn ti o mã pin ogun on pe igbakigba ti on ba mã gbe iyawo, obinrin ti o jẹ ọmọ Ajédùbúlẹ̀ ni on o kọ fẹ ati pe ko gbọdọ fẹ omiran tẹle e titi ọdun mẹwa. Kò tilẹ wipe ko gbọdọ ni ju obinrin kan lọ. Ọjọ keji ti nwọn ti ka akọsilẹ yi ni Àdìitú ti fi ọwọ si iwe pẹlu awọn ti o npin ogun bi akọsilẹ ti sọ.

Dajudaju, ẹ o bẽre ibiti awọn obi Àdìitú wà, ati iru ipo ti nwọn wa lati ọjọ ti ọmọ wọn ti lọ. Ipọnju ko fi wọn silẹ fun iṣẹju kan, o wọ̀ wọn l'ọ́rùn bi ẹwu ni. Ajedubulẹ si jina pupọ si Ilakọsẹ, ati pãpã ọkọ oju omi ni enia nilati wọ lọ sibẹ bi o ba fẹ lọ. Enia le ba ọna ilu Ifẹhiniti lọ ṣugbọn ọkọ nã ni oluwarẹ yio wọ de nkan bi mẹ̃li mẹwa si Ìfẹ̀hìntì. Ọmọ yi ko gburo awọn obi rẹ rara fun gbogbo igba ti o fi wa ninu igbo, ṣugbọn bi o ti de Ajédùbúlẹ̀ ti nkan bẹrẹsi dara fun u ni o ti bẹrẹsi fi owo ranṣẹ si wọn ni Ilakọsẹ, o tilẹ tun nfi onjẹ ati aṣọ ranṣẹ pẹlu.

Owo ti Àdìitú ni nisisiyi pọ pupọ ju eyiti enia le sọ nitori owo ti yio mã ri lọdọ̃dun lori ilẹ ti nwọn ti nwa gõlu ju ẹgbẹrun apo owo dãdã.

O wa mura lati lọ wo baba ati iya rẹ, Òbìrí-aiye ati Ìpọ́njú-dìran. O ra oniruru aṣọ, àrán, dàmáàsì, aṣọ oke àtàtà, sãnyan, ẹtù, alãri, àdìrẹ, aṣọ ẹlẹpa ati bẽ bẽ lọ. O ran pupọ ni ìró obinrin ti yio fi fun iya rẹ, o wa ra oniruru àwo ti o dara, tanganran ati oniruru ife mimu ẹmu, ati gàlafì fun ọti mimu. O ra ojilugba iṣu, ãdọta apo elubọ, ogoji apo gari, ãdọta garawa epo, ogoji garawa ororo ẹpa, ogoji garawa ororo ẹgusi, agbọ̀n obi gbanja mẹwa, ti abata mẹwa, ti orogbo mẹwa, apo iyọ mẹfa, ti ata mẹfa, ti alubọsa mẹfa, ti ata rodo mẹfa, ti ata wẽwẽ mẹfa ati ti tomati mẹfa. O wa ra ewurẹ mẽdọgbọn, aguntan mẽdọgbọn, ati àgbò mẽdọgbọn. O ko gbogbo iwọnyi si ọkọ, o di ilu Ifẹhinti. O gbe mọto ayọkẹlẹ gbọlọku meji lọwọ pẹlu. Ilu Ifẹhinti ni o fi mọto si nitori ọna mọto ko de Ilakọsẹ.

Gbogbo nkan ti Àdììtú ra yi, o fẹ fi ṣe ajọyọ ipade on ati awọn obi rẹ ni.

Igbati o mã kuro ni ilu Ifẹhinti, o gba alãru ki nwọn ba a ko awọn nkan gbogbo ti o ra ni.

Nwọn de Ilakọsẹ ni dẽdẽ agogo mẹwa owurọ lọjọ ti nwọn de ibẹ, iyalẹnu l'o si jẹ fun Àdììtú-Olodumare nigbati ẹniti nwọn kọ pade, ti o jẹ ẹniti ngbe eti ile wọn gãn, ti o tun jẹ ibatan pẹlu wi fun u pe on ko ro pe awọn obi rẹ wà ni ile nitori o pẹ diẹ ti on ti ri wọn mọ, on ro pe nwọn lọ si oko.

Lõtọ, Àdììtú wọle. Ile kan gbínríngbínrín, ko gbọ ohùn ẹnikẹni. Igbati o wa yọ oju wo iyara ti awọn obi rẹ ngbe ni o to mọ nkan ti o ti ṣẹlẹ. O ba wọn lõtọ, o ba egungun wọn ti o kun ilẹ kitikiti. Nwọn ti ku. O to ọsẹ mẹta dãdã ti nwọn ti ṣe alàì si ni on wọle. Gbogbo owo ti o ti nfi ranṣẹ si wọn, ẹnikẹni ko fi jiṣẹ. Ebi pa ati baba ati iya Àdììtú-Olodumare ku, awọn mejeji ku si oju kan, bi enia ba si ṣe akiyesi egungun wọnni bi nwọn ti ri, oluwarẹ ko ni ṣai mọ pe, láì ṣe aniani, nwọn di ara wọn lọwọ mu titi nwọn fi ku ni.

Ọmọ nã woke o wo salẹ omi bẹrẹsi dà wẹrẹrẹ lati inu oju rẹ, Àdììtú ni :

"Baba mi, ha ! Baba mi. Iya mi, ye ! iya mi. Egungun apa yi, ti baba mi ni; egungun ẹsẹ yi, ti iya mi ni ; egungun aiya yi, ti baba mi ni ; agbari mejeji yi, ti awọn obi mi ni. A ! Ẹnyin ti ẹ bi mi, mo fi yin silẹ pẹlu ẹran ara, mo ba yin ni egungun wọ́nganwọ̀ngan ! Bi ẹ ko tilẹ l'owo, ẹ ti nsọrọ si mi ri, ṣugbọn loni, ati sọrọ ko ṣẽ ṣe. A ! Olodumare, aiye yi ko ye mi. A ! Ẹlẹda, nko mọ itumọ aiye, adiitu ni. Ebi pa baba mi titi o fi ku, ebi pa iya mi titi o fi lọ. Emi là, emi lu, emi ní ilẹ, emi ni ile, mo ni owo tabua ! Bawo ni iba ti dun to, Iwọ Ẹlẹda mi, pe dandogo ti mo mu wa, ki baba mi wọ ọ ! Ṣokoto arúmátá ti mo mu wa, ki baba mi wọ ọ ! Aṣọ àrán ti mo mu wa, ki iya mi ro o ! Gele aran ti mo mu wa, ki iya mi we e ! A ! Idãmu de ba mi, ọkan mi dàrú, o dabi ìgẹ̀dẹ̀gẹ́dẹ̀ isalẹ akengbe ọti ọkà, inu mi kan bi ẹmu ọjọ mẹjọ. Ireti ti mo ni ti pọ ! O pọ, o pọ gidigidi. Ireti mi ni pe ki npa ewurẹ ki iya mi jẹ, ki npa aguntan, ki iya mi jẹ, ki nse ọbẹ̀ ewẽdu ki iya mi fi jẹ àmàlà gbigbona, ki nse mọinmọin ki iya mi fi






'Mo fi yin silẹ bi ẹran ara mo ba yin ni egungun wọ́nganwọ̀ngan'

jẹ ẹkọ. Ki baba mi joko, ki iya mi joko, ki nwọn mã da ọbẹ ẹja pọ mọ ti elédé, iwe adiẹ pẹlu ti pẹpẹiyẹ, ki nwọn pa ẹdọ ẹran pọ̀ mọ́ ṣàkì, ike mãlu pẹlu ahọn, ki nwọn gbadun ara wọn bi o ti yẹ. A ! Ireti mi d'ofo, ireti mi d'ofo, ireti mi d'ofo.

"Ẹnyin ọmọ araiye, ẹ ko le mọ bi ibanujẹ yi ti jinlẹ to, ẹnyin enia, idãmu ọkan mi ko le ye yin, afi bi ẹ ba mọ bi ibanujẹ ẹniti ireti rẹ̀ d'ofo ti to. Ẹniti ireti rẹ̀ d'ofo dabi ẹniti ó bẹ́ lati oke aja ti o bẹ lu ìṣó, ti iṣo gun l'atẹlẹsẹ ti o yọ ni oke ẹsẹ, ti ọkunrin na ko le fa ẹsẹ rẹ̀ yọ. Ó ṣubululẹ, o njẹ irora, igbati o pẹ, awọn enia de, alápá mu apa, ẹlẹsẹ mu ẹsẹ, nwọn fi gbogbo agbara fa ẹsẹ yọ, ẹjẹ bẹ́, o ntọ sọ̀ọ̀rọ̀ lati oke, o nṣan lati isalẹ, irora nã pọ gidigidi, bẹ̃ ni ẹniti ireti rẹ̀ d'ofo ri gãn. Lati oni lọ, nko ni baba mọ, Olodumare má ṣai ṣe baba mi ; lati oni lọ, ko si iya mọ, Olodumare má ṣai ṣe iya mi ; má ṣai ṣe alágbọ̀ràndùn mi, Ẹlẹda mi ; má ṣai ṣe alátọ̀nà mi, Ẹlẹda mi. Ẹrù k'ẹrù ti ó wa ti mo nilati gbe, jọwọ Olodumare, má ṣai ba mi gbe e ; irin ki rin ti o wu ti mo nilati rin, jọwọ Olodumare, má ṣai ba mi rin i, mã ba mi lọ loni, mã ba mi lọ lọla, mã ba mi lọ titi lailai, iwọ Ẹlẹda mi."

Bayi ni Àdììtú sọrọ arò, pẹlu ẹkun, pẹlu òṣé, pẹlu ìmí ẹ̀dùn, pẹlu ibanujẹ nla.

Ṣugbọn ọmọ nã ṣe oku awọn obi rẹ̀ dãdã. Ko ku ẹyọ ẹnikan ni Ilakọsẹ ti ko jẹun yo bamubamu, ko si ku ẹyọ kan ti ko mu nkan yo ki o mã ta rá-ńgọ́ rá-ńgọ́ kiri.

Oku awọn obi rẹ̀ ni o yi Ilakọsẹ pada patapata, nitori Àdììtú-Olodumare fi owo ara rẹ̀ ṣe ọna mọto lati ilu Ifẹhinti de Ilakọsẹ o si da ọ̀dà si i. Lẹhin nã, ó dá iṣẹ pataki kan silẹ ni Ilakọsẹ ti alejo fi wọ ilu ti ilu di nla, o si wa da ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ silẹ l'orukọ awọn obi rẹ̀, ọdọ̃dun ni nwọn nran ọmọ mẹdọgbọn lati Ilakọsẹ lọ si ilu nla lati lọ kọ ẹkọ nipa ìwà, ọ̀fẹ́ si ni.

Àdììtú wa ṣe ọwọ̀n nla kan silẹ l'orukọ awọn obi rẹ̀. Oju agogo mẹrin nla nla ni o wa ni oke ọwọ̀n yi ti nwọn nka wakati dãdã. Ni isalẹ ọwọn nã ni ọrọ yi wa ! "Ọwọn yi wa l'orukọ ÒBÌRÍ-AIYE ATI ÌPỌNJÚDÌRAN, A ṢE E LATI ỌWỌ ỌMỌ WỌN, ÀDÌÌTÚ-OLODUMARE." Awọn ara Ilakọsẹ a mã pe ọwọn yi ni, "Agogo Òbìrí-aiye on Ipọnjudiran."





"On l'o mã nsọ akoko fun wọn, bi o di agogo kan, a lu ọkan, bi agogo di meji a lu meji, bi o ba si ti nlù ki ohun rẹ̀ mã rin ilẹ dodo ni, ò gbọ́, gbọ̀n-ùn-ùn-ùn, gbọ̀n-ùn-ùn-ùn, gbọ̀n-ùn-ùn-ùn, ati bẹ̃ bẹ̃ lọ.

Ṣugbọn ilu Ifẹhinti ni Àdììtú ti nawo julọ patapata, nitori on tobi ju Ilakọsẹ lọ. Pupọ, ninu awọn ọmọ ilu nã ni ko mọ ọ mọ. Lọna kini, Àdììtú ti yipada, ọwọ ọlá wà lara rẹ̀," O si tilẹ dagba si i, igbati nwọn ba nwo o ninu mọto gbọlọku gbọlọku, ẹnu nya awọn ti nwọn ti mọ ọ tẹlẹ ri, ti nwọn ranti pe on ni awọn da ẹjọ iku fun ki Ọlọrun to yọ.

Igbati Àdììtú-Olodumare ti di olowo tan, awọn obinrin ilu Ifẹhinti ko jẹki o simi. Omiran a ko gõlu pa ori, a ko o pa ẹsẹ, a ko o bo ọrun, a fi tojutimu kun atike, a kùn s'apa, a kùn s'ẹsẹ, a mu salubata, a mã wọ́ gẹrẹ gẹrẹ di i mọle, di Àdììtú, ti o ti fi ọwọ si iwe pe Ajedubulẹ ni on o ti kọ l'obinrin mọle ! Bi nwọn ti ngba oju ọna ọtun wọle ni Àdììtú nmu wọn gba ti osi jade. Bi nwọn ba mọ ọ loju on nã a mọ wọn loju. Ọpọlọpọ ninu awọn obinrin ni ko nbikita nigbati nwọn ba nfẹ ba aiye ẹni ẹlẹni jẹ, bi nwọn ba ti ri owo, nwọn ko mọ ẹ̀tọ́, nwọn ko mọ ẹ̀yẹ, ati eyiti o tọ ati eyiti ko tọ ni nwọn o mã ṣe.

Àdììtú ṣe to bi oṣu kan ni Ifẹhinti ki o to kuro ki o to lọ si Ajedubulẹ. Ọjọ ti o si kọ sun ni Ajedubulẹ, o la'ala àgbá-àrà gbá kan.

# ÀDÌÌTÚ-OLODUMARE LA ALA IYANU

Ni ọjọ ti Àdììtú de Ajedubulẹ ãrẹ mu u nitori agbara rẹ ti o ti lò gbogbo fun isinku ni Ilakọsẹ ati Ifẹhinti. Ko pẹ ni alẹ ọjọ nã ti o fi sunlọ.

O wa la ala kan, o ja si ilu kan ti o ṣoro lati ṣe apejuwe fun didara. Gbogbo oju ọna ti enia nrin, kiki digi ni, gbogbo ègbé-ogiri ile, kiki digi ni. Awọn digi wọnyi si ni orişirişi àwọ. Omiran dabi aṣọ alaro, àwọ omiran ba ti ewe igi mu, ṣugbọn iru àwọ tí digi ile ba jẹ ni gbogbo ogiri ile lapa ọtun ati lapa osi njẹ. Awọn ile wọnyi tobi gidigidi. Eyiti o si tilẹ tun jẹ iyanu ni pe ara awọn enia ti enia nba pade tun dabi digi, bi ẹnikan ba nbọ niwaju enia le mã ri ẹniti nbọ lẹhin rẹ kedere, enia tilẹ le ri to mẹta tabi mẹrin lẹhin on ti nwọn tẹle ara wọn.

Gbogbo awọn ti o ti ku ni Àdììtú nri, awọn ti nwọn si mọ ọ tẹlẹ ni ode aiye nyọ mọ ọ ni. Ẹlomiràn ti o jẹ talaka paraku laiye a fi ile rẹ han a, ṣugbọn ile ti o mã fi han a yi, ọkẹ aimoye apo owo ko le kọ ọ. Ọrun gãn ni Àdììtú wà loju ala. Ko si woro ile ilẹ kan ṣoṣo, ko si si ile ti ko ni ju ọgọrun iyãra. Iyatọ ti o wa ni pe ile miran ti o ro pe ó nilati jẹ ti olowo laiye le lọ jẹ ti talaka, ki olowo laiye si mã wà bi ọmọ ọdọ. A ri awọn ti o mọ iwe laiye pupọ ninu awọn ọmọ ọdọ, a ri bãlẹ ilu nibẹ, a ri ọba ilu, a ri babalawo pataki, a ri adahunṣe, a ri Alufa Ijọ enia Ọlọrun, a ri Lemọmu pataki ni Mọṣalaşi ti gbogbo awọn wọnyi wa ni ipo ọmọ ọdọ. Ile kõkan ko ni din ni ãdọta enia, ẹni kan l'o si jẹ ọga ninu ile kọkan. Ṣugbọn ki iṣe pe gbogbo enia pataki l'aiye l'o jẹ ọmọ ọdọ ni ode ọrun, igbamiran, ọmọ ọdọ miran a ṣe e laiye a tun ṣe e lọrun, olowo miran a ni i laiye a ni i lọrun, Alufa Ijọ enia Ọlọrun miran a jẹ ọga l'aiye a tun jẹ ẹ l'ọrun, Lemọmu miran a ṣe pataki l'aiye a tun ṣe pataki l'ọrun.

Awọn ti Àdììtú ri wọnyi pãpã ko ti iri idajọ Ọlọrun. Nkan ti o wa nibẹ ni pe bi ẹnikẹni ba ti de ọrun, ní gbàrà ti oluwarẹ de, nwọn nilati kọkọ sọ fun u iru aiye ti oluwarẹ mã mã gbe





ki idajọ Ọlọrun to de fun u. Nitori ki iṣe aiye tiwa yi nikan l'o wà, aiye ti o dara ju tiwa lọ wà, eyiti ko dara to o wa pẹlu. Bi nwọn ti ṣe nmọ ọ ni yi. Olukuluku ọmọ enia ti ni ẹrù ẹṣẹ rẹ ni ode ọrun ti awọn ẹmi ti ko pamọ sinu apoti iranti fun u. Bi ó ba ti de nwọn a wo orukọ rẹ ninu iwe, were nwọn a mọ ibiti ẹrù ẹṣẹ rẹ wa, nwọn a si gbe e jade. Igbati nwọn ba gbe ẹrù yi le ori ìwọn ni nwọn to mã mọ ibiti ó mã lọ. Ẹru ẹṣẹ ẹlomiran wuwo ju ẹrù iṣẹ rere rẹ lọ. Iru awọn ẹni bẽ nilati pada lọ ṣinu aiye miran ti o buru ju aiye tiwa yi lọ. Ṣugbọn bi nwọn ko ba fẹ bẽ nwọn ni anfani ati yan ninu ki awọn mã ṣe ọmọ ọdọ fun awọn ẹni rere tabi ki awọn lọ si aiye miran ti o buru ju aiye wa yi lọ.

Eyiti ọpọlọpọ mã nfẹ yàn ni pe ki awọn kuku duro ni ọrun gẹgẹ bi ọmọ ọdọ, nitori ọmọ ọdọ ṣiṣe nibiti a nwi yi tùn gbadun ju pe ki enia jẹ ọba ninu aiye tiwa. Kini awọn ọmọ ọdọ wọnyi nṣe fun ọga wọn? Ko ju pe ki nwọn mã wo iwe iranti ki nwọn mã dahun ohunkohun ti ó ba bi wọn.

Ninu gbogbo awọn ẹmi ti mbẹ ni ode ọrun ọkan wà nibẹ ti o lagbara pupọ, on ni a npe ni Itọju Ẹmi. Orukọ Itọju Ẹmi ki ikuro lẹnu awọn ara ọrun. Ede kan ti ki itun kuro lẹnu wọn ni "Ìgbà." Bi eleyi sọrọ a ni nkan bayi bayi ṣẹlẹ ni ìgbà kan sẹhin bi tọhun sọrọ a ni nkan nã ṣẹlẹ ni ìgbà karun sẹhin. Igbati ede yi ko ye Àdììtú, o bẽre ohun ti nwọn npe ni "ìgbà" yi. Awọn ara ọrun rẹrin nwọn ni "ìgbà" ni ẹgbẹrun ọdun kan. Igba keji jẹ ẹgbã ọdun sẹhin ati bẽ bẽ lọ. Lẹhin nã nwọn tun gbadun a nlo akekuru yi. "Ọ. E." itumọ eyiti ijẹ "Ọdun Enia". Bi nwọn ba mã pe 1958 nwọn ko ni pe e ni 1958 A.D. kàkà bẽ nwọn a ni "1958 Ọ.E."

Nkan ti awọn ọga ti o wa ninu ile daradara wọnni mã nsaba bẽre lọwọ awọn ọmọ ọdọ wọn ni ọdun ti awọn enia wọn ti o wà laiye mã ku, ki awọn ba le ṣe eto ati lọ pade wọn. Idi eyi ni pe awọn ti o ba ṣẹṣẹ nti aiye bọ ki itete mọ pe awọn ti ku. Nwọn a ṣebi awọn wa loju ala ni. A mã pẹ ki nwọn to mọ pe awọn ti fi aiye silẹ.

Ni ọdõdun ni Angẹli ti a npe ni Itọju Ẹmi yi mã npin iwe ti a to orukọ gbogbo awọn ọmọ ara aiye si ka arin awọn iranṣẹ inu ile kõkan. Ọkõkan nilati ní iwe kan lọwọ. Nkan ti Àdììtú

kọ silẹ ni oju ewe kan ninu ọkan ninu awọn iwe wọnyi ni a o ka silẹ yi. A ko ni darukọ ẹnikẹni ṣugbọn a o fun wọn ni orukọ lẹta lati A de Y. Dipo ki a wipe "Ajayi," tabi "Oni" tabi "Dada" a o wipe "A" tabi ki a wipe "B" tabi "D" Bayi ni eto ṣe lọ loju ewe iwe nã :

*A* : Yio ku ni ọjọ 2 oṣu July, 1990 Ọ.E. bi o ti wù ki o gbiyanju ati ṣàì ku to.

*B* : Ọjọ iku eleyi ni ọjọ 2 oṣu January, 1980 Ọ.E. ṣugbọn aisan kan yio ṣe e ni ọjọ 3 oṣu March, 1971 Ọ.E. Bi awọn ọmọ araiye ko ba tọju rẹ dãdã, Itọju Ẹmi yio paṣẹ ki iku lọ mu u.

*D* : Ọjọ iku eleyi di 2020 Ọ.E. bi nwọn ba tọju rẹ dãdã. Aisan yio ṣe e ni ọjọ 4 oṣu May, 1999 Ọ.E. Itọju Ẹmi ti wipe bi nwọn ko ba wa Dokita dãdã fun u, on yio paṣẹ ki Iku lọ mu u.

*E* : Ọjọ iku gãn, ọjọ 2 oṣu January, 2000 Ọ.E., ṣugbọn afi bi ko bá bá mọto ti o nti Eko lọ si Ibadan ni agogo mẹta ọsan rin ni ọjọ 3 oṣu June, 1980 Ọ.E. Bi ó ba rin lọjọ nã ní akoko ti a sọ yi, mọto yio ṣe èṣe, yio si ku..

*F* : Ko ni aisan pataki kan di ọjọ 5 oṣu September, 1990 Ọ.E. Ọjọ nã l'ọjọ iku pe, yio rọra fi aiye silẹ wọ̃rọ ni.

*G* : Afi ti ko ba wọ ọkọ oju omi ti yio ti Eko lọ si Ejinrin ni ọjọ 8 oṣu December, 2021 Ọ.E. bi o ba lọ wọ ọkọ igi ti agogo mẹsan, yio ku ṣugbọn ọjọ iku gãn ni, ọjọ 4 oṣu February, 2023 Ọ.E.

*GB* : Bọya ni Itọju Ẹmi ko ni fi ran Iku lọ mu eleyi wa ni ọjọ 13 oṣu November, 1963 Ọ.E. nitori awọn ara ile rẹ ko ní igbẹkẹle si Dokita ti a kọ l'ọna ti Oyinbo, nkan ti nwọn gbẹkẹle ni pe bi oṣo ati ajẹ ko ba ti ni ọwọ si aisan yi, yio là ! Bẹ̃ni iṣẹ abẹ ni aisan nã gbà, Dokita l'ó si le ṣe e. Ọjọ iku gãn, ọjọ 8 oṣu May, 1994 Ọ.E.

*K* : Bi iya ọmọ yi ba fun u ni àgbo lile ti nwọn juwe fun u fun ọsẹ meji, dandan ni ki Itọju Ẹmi paṣẹ ki Iku lọ mu u ni ọjọ 24 August, 1963 Ọ.E. Ọjọ iku gãn, ọjọ 22 oṣu October, 2029 Ọ.E.

*L* : Ó mà ṣe o ! Bi eleyi ko ba fi ọrẹ rẹ agabagebe silẹ yo fun u ni majele ninu ọti ni ọjọ 7 oṣu July, 1977 Ọ.E. Itọju





Ẹmi si nilati paṣẹ pe ki Iku lọ mu u. Ọjọ iku gãn, ọjọ 8 oṣu June, 1989 Ọ.E.

*M* : Afi bi ó ba fi obinrin ti ó kọ́ fẹ silẹ. Bi bẹ̃ kọ, obinrin nã yio pa a ni ọjọ 3 oṣu April, 1981 Ọ.E. Ọjọ iku gãn, ọjọ 3 oṣu January, 1999 Ọ.E.

*N* : Bi ko ba fi imukumu silẹ, ọti ati ẹmu yio ti ba ifun eleyi jẹ to bẹ̃ ti Itọju Ẹmi yio fi nilati ran Iku lọ mu u ni ọjọ 2 oṣu July, 1985 Ọ.E. Ọjọ iku gãn, March 3, 2000 Ọ.E.

*O* : Bi eleyi ba lọ si ibi ija nla kan ti yio ṣẹlẹ ni ọjọ 14 oṣu August, 1980 Ọ.E., ó nilati ku sinu ija nã. Ọjọ iku gãn, ọjọ 7 oṣu June 2003 Ọ.E.

*Ọ* : Eleyi yio ṣiwere nigbati ó ba di ọmọ ogun ọdun gẽre, eyini ni January 1, 1996 Ọ.E., bi nwọn ko ba si tete mura si aisan nã yio fi ọwọ ara rẹ pa ara rẹ ni ọjọ 2 February, 1998 Ọ.E. Ọjọ iku gãn, ọjọ 3 oṣu March, 2047 Ọ.E.

*P* : Owu jijẹ le mu ki eleyi sọ ẹmi rẹ nù ni ọjọ 12 oṣu November, 1989 Ọ.E. afi ti ko ba lọ si ile rẹ lọjọ nã, nitori lọjọ yi, ti o ba nti idalẹ bọ lọ si ile, yio ba ọkunrin miran pẹlu iyawo rẹ ninu iyara, eleyi le si mu ki o yinbọn pa iyawo ki o tun pa ara rẹ. Ọjọ iku gãn, ọjọ 13 September, 2009 Ọ.E.

*R* : Ko ni si aisan nla kan ti yio ṣe eleyi titi ọjọ iku rẹ yio fi pe. Ọjọ nã ni ọjọ 13 September, 2019 Ọ.E.

*S* : Afi bi ko ba lọ wẹ ninu omi okun ni ọjọ 1 oṣu January, 2001 Ọ.E. ni ko ni fi ku, akoko iku gãn ni ọjọ 8 oṣu February, 2019 Ọ.E.

*Ṣ* : Ori eleyi yio dede dàrú ni ọjọ 6 oṣu June, 1987 Ọ.E. yio si yinbọn jẹ.

*T* : Bi ó ba lọ si oko ni January, 2007 Ọ.E. ti ko ba wolẹ dãdã yio tẹ ọka ni iru mọlẹ, ejo nã yio bu u ṣan, Itọju Ẹmi yio si paṣẹ ki Iku lọ mu u. Ọjọ iku gãn, ọjọ 8 oṣu February 8, 2019.

*U* : Bi nwọn ko ba tete bu apá fun eleyi, ṣanpanna yio gbe e lọ ni ọjọ 9 oṣu July, 1986 Ọ.E. ọjọ iku gãn, ọjọ 30 ṣu January, 2003 Ọ.E.

*W* : Bi iyá eleyi ko ba m'oju to o yio ṣubu lati oju ferese ni ọjọ 10 October, 1964. Ọjọ iku gãn, July 2, 2035 Ọ.E.

*Y* : Orun ni eleyi yio sùn ni ọjọ 31 oşu December, 1999 Ọ.E. ti ko ni ji mọ. Eyi ni ọjọ iku rẹ̀.

Bayi ni awọn nkan ti Àdìitú-Olodumare kọ silẹ ni oju ewe iwe ọkan ninu awọn ẹmi ti nwọn ti ku şugbọn ti nwọn nşe iranşẹ ni ode ọrun.

Bi o ti kọ eleyi silẹ tan ni Àdìitú wo iwaju ti o ri awọn adiẹ, pẹpẹiyẹ, ewurẹ, aguntan, ẹiyẹle ati oniruru awọn ohun ọsin gbogbo ti nwọn tẹle ara wọn ti nwọn nlọ gẹ̀rẹ́ gẹ̀rẹ́ gẹ̀rẹ́, igbati o si wadi lọwọ ẹnikan ibiti awọn wọnyi nlọ, onitọhun şe alaye pe nwọn nlọ to ara wọn si ibiti Ẹlẹda ti pa l'aşẹ fun wọn ni, nitori o nto akoko orin owurọ fun yiyin Ọlọrun Ọba l'ogo.

Ko pẹ lẹhin eyi lõtọ ti orin bẹrẹ, ti gbogbo nkan ti o wa nibẹ bẹrẹsi kọrin ti nwọn nyin Ọlọrun l'ogo. Ilẹkun ile kọ, ferese kọ, oju ọna ti a ntọ kọ, ohùn gbogbo wọn si pa pọ şe ọkanşoşo. O dùn to bẽ ti didun nã şoro lati şapejuwe. Eyiti o jẹ iyalẹnu ju gbogbo rẹ̀ ni tayọtayọ ti gbogbo ẹmi ti enia nri fi nkọrin, nwọn nkọ ọ pẹlu ẹrin, nwọn nkọ ọ pẹlu ayọ, ẹnikẹni si le ri i loju wọn bayi gbangba pe orin ayọ ti nwọn nkọ, inu l'o ti wa, nwọn fẹran Olodumare tọkantọkan ni. Igbati o ba yẹ ki nwọn ke, nwọn a ke dãdã. Igbati o ba yẹ ki nwọn rẹ ohùn silẹ, nwọn a rẹ ẹ silẹ. Orin nã dun tayọ.

Lẹhin eyi ni Àdìitú ri ẹgbọn rẹ̀ kan ti o ti ku. Inu rẹ̀ dun pupọ lati ri aburo rẹ̀ yi o si nfẹ lati fi ibiti baba rẹ̀ wa han a, şugbọn o ni on ko ni jẹki awọn gba ọna ti awọn o fi tete de ọdọ Obìrí-aiye, nitori on nfẹ fi nkan han a diẹ ki o to de ọhun. Bi nwọn ba nfẹ yara, yio sa sọ fun digi ti o wa ni ilẹ ti nwọn nrin ki o gbe awọn lọ ni. Digi ni yio sun ẹsẹ wọn gẹrẹ gẹrẹ ti nwọn o fi de ọhun.

Ẹgbọn Àdìitú yi mu u wọ inu ile nla kan lọ. Ile nã tobi ju ile kile ni ode aiye. Ile nã ni awọn ara ọrun npe ni Ile Ọpẹ́. Gbogbo ẹ̀gbẹ́ ogiri ile na, lati ilẹ de oke patapata ni nwọn kan ẹ̀kàn mọ ti nwọn gbe apo kõkan kọ gbogbo awọn ẹ̀kàn nã lọ. Ọkunrin na dahun o ni, "Ile yi wa fun gbogbo enia ni ode aiye," ile nã ni a npe ni "Ile Ọpẹ," apo ti o si ri wọnni ni a npe ni "Àpò ọpẹ." Ẹni kõkan ninu aiye ni o ní apo ọpẹ kan. Inu eyi ni a ko iye ọpẹ ti oluwarẹ ti gba ri lati ọjọ ti o ti de





inu aiye si. Bi enia ba l'owo ẹni melo l'o fi owo rẹ̀ şe ni õre, ẹni melo l'o wa dupẹ õre lọwọ rẹ̀? Ẹni melo l'o jẹ alaimore ti oluwarẹ ti şe lõre ti o jẹ pe Ọlọrun Ọba nikan l'o le dupẹ. Ẹni melo ni oluwarẹ fi nkan ta l'ọrẹ ri ni ode aiye?—Gbogbo iwọnyi wa ninu apo ọpẹ oluwarẹ̀, nwọn gbe e kọ ẹ̀gbẹ́ ogiri.

Ile nla ragbaja kan tun wa ti Àdìitú wọ̀. Eleyi kun fun ogunlọgọ apoti ti nwọn tun to lọ bẽrẹ orukọ ti nwọn kọ si ẹgbẹ apoti kõkan ni, "Işẹ isin ọmọ enia." Owo ti ẹnikẹni ba da fun işẹ kişẹ ti o ba şe laiye fun isin rẹ̀ ni nwọn fi ra aşọ sinu apoti kõkan ti a npe ni aşọ ọrun. Iye ti onigbagbọ kan ba da fun işẹ şõşi rẹ̀ yala fun ile kikọ, tabi sisan fun awọn ti nşişẹ, ẹni bi alufã tabi awọn oşişẹ miran gbogbo owo wọnyi ni nwọn fi ra aşọ ọrun sinu apoti fun u. Bakanna si ni fun onimale tabi aborişa. Işẹ kişẹ ti oluwarẹ̀ ba ti şe fun işẹ isin, nwọn nilati san owo rẹ̀ fun u ni ọrun.

Şugbọn ninu apoti kõkan ni kini kan bayi wà ti nwọn npe ni Akọ-okuta-ọrun. Şe ni eleyi mã nta bi işu, o si wuwo pupọ, o wa fun bi iwa oluwarẹ̀ ba ti dara si, nitori enia le mã lọ si ile isin lojojumọ, şugbọn, sibẹ, ki o buru ju eşu lọ.

Bẽni o yẹ ki apoti oluwarẹ̀ wuwo nitori on ni Maleka Idajọ fi mã nsọ iru ọrun ti o yẹ ki oluwarẹ lọ nigbati o ba ti ku tan. Bĩ enia ba ti de bode ọrun, ìwọ̀n nla bayi ni nwọn o gbe jade lati fi wọn ẹrù ẹsẹ rẹ̀ bi a ba fi we işẹ rere. Awọn aşọ ti o wa ninu apoti işẹ isin ko wuwo ju bẽ lọ, nitorinã, bi enia ba ti gbe apoti kan le ori ìwọ̀n ti o gbe ẹrù ẹsẹ le ìwọ̀n lodi keji lâì jẹ pe nkan ti o wuwo tun wa ninu apo işẹ isin ẹrù ẹsẹ yio tẹ̀wọ̀n ju işẹ rere lọ. Akọ-okuta-ọrun l'o mã njẹ ki işẹ rere tẹwọn dãdã. Apoti işẹ isin le tobi dãdã şugbọn ki akọ-okuta-ọrun rẹ̀ má ju kekere lọ, nitori eyi, ko ni tẹwọn ju bẽ lọ. A tun nri ẹlomiran ti apoti işẹ isin rẹ̀ ko ju ẹsẹ bata kan ni ibu ati ni òró şugbọn okuta ọrun rẹ̀ lè fẹrẹ wuwo to ogun okuta kòkó dãdã.

Nigbati a nsọrọ pẹ ọrun ti oluwarẹ̀ o lọ, o le şai ye ni ju bẽ lọ. Bayi ni, bi enia ba ku o ni ibiti o nilati wà titi Olodumare yio fi şe idajọ, bẽni ọpọlọpọ ti ku ni ẹgbẹgbẹrun ọdun sẹhin ti idajọ ko tĩ kàn wọn. Awọn ẹlomiran ninu awọn ti o şẹşẹ

de nilati pada si ọrun miran ti o tun buru ju aiye tiwa yi lọ, ṣugbọn eleyi ki iṣe ọrun apãdi.

Nigbati enia ba ro bi aiye tiwa yi ti buru to ko ni fẹ ki on ku ki on tun lọ si ibiti o buru ju bẽ lọ, ṣugbọn, ìwà ni. Bi enia ba nhuwa gẹgẹ bi isin ti o nsin ti wi, dandan ni ki ẹrù ìwà rere rẹ tẹ̀wọ̀n ju buburu lọ. Ṣugbọn bi enia dá owo titi, ti o lọ si ibi isin titi, ti o ṣiṣẹ ti gbogbo enia yio fi ri i titi, aṣọ ni nwọn le fi owo iṣẹ oluwarẹ̀ ra, ko si le wuwo. Igbati nwọn ba gbe ẹrù ẹṣẹ si apakan fìn ìn ni ẹru ẹṣẹ yio fa rere lọ silẹ. O pari fun oluwarẹ̀ ni eyini. Bi ẹru ẹṣẹ ati iwa rere ba mọ bakannã, iru ọrun ti a nsọrọ rẹ yi ni oluwarẹ̀ yio lọ, o dara ju aiye wa ni igba ẹgbãgboje. Bi iwa rere ba tẹ̀wọ̀n ju iwa buburu dãdã, nwọn a tun fi oluwarẹ ranṣẹ si ọrun ti o dara ju eyiti Adiitu ri lọ. Olodumare nikan l'o le mọ bi ọrun eyini yio ti dara to nitori eyiti Àdìtú de dara pupọ.

Igbati nwọn kuro ni ile yi ni nwọn tun lọ si ibomiran. Ibiti nwọn lọ yi ni ile "Àkùkọ Ọ̀run." Nitori ko si pe ilẹ nṣu okunkun nbo ilẹ tabi oṣupa nyọ ko njẹ̀ki awọn ti o ba ṣẹṣẹ ti aiye de mọ bi ọjọ ti nlọ. Nitori eleyi, Olodumare ti ṣe ẹda kan ti a npe ni "Àkùkọ Ọ̀run." Igbati nwọn wọ inu ile nã ti nwọn ri ọkunrin kan, nwọn wi fun u pe awọn fẹ ri Àkùkọ Ọ̀run. Ọkunrin nã bẽre, o ni, nwọn nfẹ fi ẹsẹ rin ni. Àdìtú Olodumare dahun o ni, bẹ̃ni. Ṣe ni ẹniti o mu u lọ ati ẹniti nwọn nba sọrọ bu sẹrin, nitori ki ẹnikẹni to le rin de ibiti Àkùkọ Ọrún wà, irin oṣu mẹfa bamubamu ni, ile na ni o ga ju gbogbo ile ọrun ati aiye lọ, ori rẹ si ni Akukọ Ọrun ngbe, ki ijẹun ki isi ikuro ninu iyãra kan titi lai.

Akukọ ọrun yi, ati oju ati imu rẹ bi ti enia l'o ri, ṣugbọn ẹsẹ rẹ mejeji, bi ti adiẹ ni, o tun wa lọ ni ogbe lori o si ni iyẹ lapa, ṣugbọn o ga to enia dãdã. Kì ikọ bi akukọ nitori ẹnu enia l'ó ni, gẹgẹ bi apẹrẹ bi o ti ma nke ni yi : "O di agogo kan : — : — : — : — ọjọ kẹta : — : — : — oṣu keji : — : — : — ọdun 1956 : — : — : — : — Iṣiro ọmọ enia : — : — : — : —, O di agogo meji : — : — : — : — ọjọ kẹfa : — : — : — : — oṣu kẹrin : — : — : — : — ọdun 1957 : — : — : — : — iṣiro ọmọ enia : — : — : — ati bẽ bẽ lọ.





Igbati awọn ti nrẹrin ti fi Adiitu rẹrin tan ni nwọn ti kọju si ilẹ lori eyiti nwọn duro, nwọn sọrọ si i, nwọn ni, "Gbe wa lọ sọdọ akukọ ọrun." Nwọn fẹrẹ má iti idakẹ tan ti nwọn ba ara wọn niwaju ẹda nã ti o loju enia, imu enia ti o si wa ni ogbe lori bi akukọ. O ki wọn dãdã, o ki Àdìtú kãbọ lẹhin eyini nwọn wa si ibiti nwọn ti lọ.

Bi nwọn ti jade ni Àdìtụ́ ri awọn ẹnikan ti nwọn pa àtẹ ti nwọn nta onjẹ, o ba wi fun ẹnikeji rẹ ki o mu on lọ si ọdọ wọn.

Bi o ti de ibiti awọn alatẹ wọnyi wa o ni, "Ha, nko ro pe ẹ ni nkan ti o wu mi jẹ." Gbogbo awọn ti o tun wa nibẹ gbe okiti ẹrin, ẹnikan ninu wọn si dahun o ni, "Awa ti wà ki aiye to wà lati ọjọ ìwà, ko si onjẹ ti a ko ni ri, kil'o fẹ jẹ?"

Àdìtú fesi o ni iyan ati ọbẹ adiẹ ni o wu on lati jẹ. Ko fesi ọrọ yi ti iyan ati ọbẹ adiẹ fi bọ siwaju rẹ, ṣugbọn nigbati ẹniti o nta ọja fẹ gbe awo fun Ậdìtú, awo ko ṣẽ gbe, o lẹ̀ mọ ori nkan ti nwọn ti nta ọja. Ẹni nã ba bẽre o ni, "Tabi o ko ti ifi ara enia silẹ?" On nã dahun pe "O tì o." Onitọhun ba dahun o ni "O ko le jẹ onjẹ ọrun nigbana, mo ṣebi o ti kuro laiye ni."

Lẹhin eleyi ni ẹgbọn Àdìtú mu u lọ si ọdọ baba rẹ, o ba ilẹ sọrọ bayi, were ni nwọn ba ara wọn niwaju Òbìrí-aiye, baba Àdìtú-Olodumare.

Àdìtú ko mọ baba rẹ mọ, kí iṣe pe ara baba rẹ ti yipada si digi bi ara awọn ara ode ọrun, nitori ko pẹ ti on de ọhun, ṣugbọn ara rẹ ti yipada di ti ọmọde. Ori ti o ti kun fun ewu, ko ni woro ẹyọ ewu kan, ṣe ni irun ori rẹ dudu mìnìjọ̀ ti o ndan. Gbogbo ara ti o ti hunjọ ti yipada o ti di didan, Òbìrí-aiye di ọmọde pada igbati o si woye pe ọmọ on ko mọ on mọ, o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni :

"Àdìtú-Olodumare, ọmọ mi, emi, Òbìrí-aiye baba rẹ ni yi, emi ni, emi nã ni. Mo dupẹ, mo dupẹ mo dupẹ pupọ fun ẹhin emi ati iya rẹ ti o ṣe dãdã. Igbati a de ihin l'a to ri i pe o fi owo pupọ ranṣẹ si wa ki a to kuro ni aiye, awọn ti o fi ran ko fi jiṣẹ fun wa rara, nwọn ko tilẹ fi tọ́rọ́ laṣan jiṣẹ fun ni. Ọjọ kejila, ti emi ati iya rẹ ti fi ẹnu ba onjẹ mọ ni a kuro ni ibugbe awọn ọmọ enia ti a wa sihin. Tiwa ni gbogbo ile yi a si ni ãdọta iranṣẹ. Ẹni kọ̃kan ni mẹdọgbọn mẹdọgbọn, emi ati iya rẹ ni a si jọ

..gbe. Iya rẹ ṣẹṣẹ jade nisisiyi ni. Ó lọ ki ọrẹ rẹ̀ kan ti o wà ni ẹgbãfa mẹ̃li sihin, ni iṣiro ọmọ enia, ṣugbọn yio ti de ọhun bayi, ó ti to iṣẹju kan ti o ti lọ. Iwọ ọmọ mi, bi o ti ṣe nhuwa ni ki o ṣe mã huwa lọ. Iwa otitọ ti mo fi le ọ lọwọ l'ode aiye, má ṣai mã fi ara rẹ si ipò ọmọnikeji ki o to mã huwa si ọmọnikeji, ãnu kò tà pupọ lode aiye ṣugbọn o tà lode ọrun, bi ẹnikan ba wa ninu iyọnu, ti o fa a yọ ninu iyọnu, bi ó tilẹ kuro ninu iyọnu tan ti ko mọ-ọ, Ọlọrun Ọba ti kọ eleyini silẹ fun ọ, ó wà ninu apo ọpẹ́, ko si ni ṣai mu ki iṣẹ rere rẹ wuwo dãdã ni ọjọ ti a o ba wọn ọ. Si wo o, ọmọ mi, ẹniti iṣẹ rere rẹ̀ ko ba tẹ̀wọ̀n, oluwarẹ yio tun lọ si ọrun ti o buru ju aiye lọ! Iwọ, yọ oju wo ibiti ọpọlọpọ enia ba pejọ si ni ode aiye, yala ninu ile isin Onigbagbọ tabi ninu mọṣalasi awọn onimale, tabi egúngún pataki kan jade enia wọ́ tele e, kil'o ri? Ẹnikọ̃kan ninu wọn ni ó ní ohun ti ó nbá ja labẹ aṣọ. Ti eleyi le jẹ lakuregbe, ti onitọhun le jẹ ori fifọ, ti ẹnikan le jẹ ẹhin didun, aisan ẹlomiran ko ṣẽ sọ si ode, bẹ̃ni ko si bi ọba enia ti tobi to tabi ti ọlọgbọn enia ti gbọn to ti Olodumare ko le wipe ki iku lọ mu u wa nigbati o wu u. Idarudapọ ero ọkan nkọ, ki ọkọ mã ṣe nkan ti aya ko fẹ, ki aya mã huwa eke si ọkọ, ki olowo fi owo rẹ́ ni jẹ, ki ọlọla fi ọwọ ọlá gba ni loju, láì ṣẹ̀ láì rò, ki ẹnikan mã dede binu ẹni, ki a sọrọ ẹni ẹlẹni lẹhin, ki a ba orukọ rẹ̀ jẹ patapata, iru nkan bayi l'ó kún inu aiye, lõtọ awọn ẹlomiran a ma yọ̀ ṣugbọn ayọ̀ aiye ko njinlẹ rara, ẹniti o bimọ lè ṣai ri owo jẹun, ẹniti o ri owo jẹun le ṣai bimọ, enia le ri owo jẹun ki o ri ọmọ bi, ki ọmọ ya òpè tabi ki o ya garawa ati bẹ̃ bẹ̃ lọ, iwọ wa wo ọ, ọmọ mi, njẹ ki l'o buru bi pe ki ẹnikan tun lọ gbe inu aiye ti o buru ju eyi lọ."

Bẹ̃ni ibẹ ni yio wa titi Olodumare yio fi ṣe idajọ ohun gbogbo. Igba wo ni a mọ̀ ti eleyi yio jẹ? Ẹgbẹrun ọdun ọmọ enia, igba kan lasan ni ni ode ọrun. Ẹlẹda pãpã mọ eyi o si ti ṣí gbọngan Idajọ nisisiyi kọja igba meji dãdã, eyini ni, ẹgbã ọdun ọmọ enia, ti nwọn ti bẹrẹ idajọ, sibẹ nwọn ko iti pari ẹjọ idaji awọn ọmọ enia ti nwọn ti fi aiye silẹ ki a to bi Oluwa wa, nitori ẹjọ ẹlomiran npẹ, omiran ngba ju ọdun ọmọ enia kan, nitori aiye ni eke wa, aiṣododo ko si ni ode ọrun. Ọmọ mi, mura si iwa rẹ, o to nisisiyi ki o mã lọ, nijọmiran ng o tun pe





ọ wa, ng o si ti gba iwe silẹ de ọ ti o le fi lọ woran diẹ ni gbọngan Idajọ Olodumare. Nitorina mã lọ ni ti oni na o digba o. Hà! mo gbagbe, o ko iti ri iya rẹ, jẹki nranṣẹ si i, yio de ni iṣẹju kan, duro diẹ."

Igbati o wi bayi ni Àdììtú Olodumare dahun o ni, "Baba, mo ṣe bi ẹ ni ibiti iya mi lọ to ẹgbẹfa mẹ̃li, bawo l'ó ṣe le de ni iṣẹju kan? Òbìrí-aiye rẹrin ni ode ọrun o ni, "Eyini ko ṣoro fun awa ti a wa ni ẹmi a yatọ si ẹnyin.. Awa le gbe ẹsẹ ni Eko ki a fi balẹ ni Kano, a le gbe ẹsẹ ni Ṣokoto ki a fi balẹ ni Ilu Ọba." Bi ó ti wi bayi, o sọrọ si ogiri kan, iṣẹju kan pẹ Ipọnju-diran iya Àdììtú-Olodumare yọ jade.

Ṣugbọn Àdììtú ko mọ iya rẹ̀ mọ ati pãpã tí iya rẹ̀ wọ iru aṣọ ti baba rẹ̀ wọ, Ara iya nã tun ti yipada pupọ, ko hunjọ, bi ti atijọ, O ndan gbã ni. Irun ori rẹ̀ ti o si ti nfunfun diẹdiẹ tẹlẹ ri ko ni funfun kan rara mọ ṣe ni ara rẹ̀ ndan gbọ́rọ́ ti o tutu nini ti o fa ni mọra. Igbati iya rẹ̀ si tilẹ tun wi fun u pe Ipọnju-diran ni on, ti ọmọ ko tun ṣe bi ẹni gbagbọ ni Òbìrí-aiye ba fi han a pe ara ọrun ni awọn o wi fun Ipọnju-diran iyawo rẹ̀, o ni, "Ipọnju, jẹki a yi'ra pada si bi a ti ri laiye fun u" kil'o wi bẹ̃ ṣe? Were ni ara awọn mejeji yipada ti nwọn ri bi nwọn ti ri laiye, ẹwu akisa ọrun Òbìrí-aiye, ṣokoto jalajala idi rẹ̀ lode aiye, ẹrẹkẹ rẹ̀ ti o ti gbẹ ti o ri pẹlẹbẹ nitori ebi, ara rẹ̀ ti o dabi ara ọpọlọ nitori àìwẹ̀ fun àì ni owo ọṣẹ, gbogbo iwọnyi l'o fi ara han gedegbe. Bakannã si ni Ipọnju-diran, aṣọ idi rẹ̀ faiya l'apakan, gele ti o wa lori dabi okun ṣokoto lọwọ akisa, ara gbogbo ri bàgìbàgì, pari ẹrẹkẹ ri pẹlẹbẹ, iṣan ọrùn yọ o ri ṣanranṣanran, oju jìn sinu, wòǹwò, ọwọ ri jọwọlọ, ẹsẹ ri jọwọlọ, igba aiya ri kẹkẹrẹ, egungun ọrun, egungun ẹhin, egungun ihà, gbogbo wọn l'enia le ka lati ode ara. Igbati Àdììtú wo awọn obi rẹ̀ o bu si ẹkun, nitori o tun ran a leti iya ti o jẹ wọn lode aiye, ṣugbọn o wa mọ wọn pe awọn ni gãn.

Igbati baba rẹ̀ tun pa ara da si ipo wọn ọrun, ti iya ṣe bẹ̃ ni nwọn tun bẹrẹ ọrọ sisọ. Baba rẹ̀ ni, "Àdììtú, a yi ara pada bẹ̃ ki o ba le mọ wa ni, ṣugbọn a ko si ninu iya mọ. Nkan ayọ ni ni fun wa nigbati a ba nri i pe aiye tirẹ dara ju tiwa lọ. Mo mọ pe o ko iti ini obinrin, igbati o ba mã ni i, aburo ọrẹ rẹ

kan ni obinrin nã yio jẹ, on ni Olodumare da mọ ọ bi ó ti da
iya rẹ mọ mi. O tun ni nkan lati bere bi? Nitori akoko nt
ki o mã lọ?"

Àdìitú dahun o ni, "Baba, ibẽre kan ni mo tun fẹ ṣe. Igbati
ẹ wipe Ẹlẹda ti bẹrẹ idajọ awọn ọmọ enia, ati pe o ti bẹrẹ t
lé ní ẹgbã ọdun ko si ti ipari idajọ idaji awọn ti o ti wa ni aiy
ki a to bi Oluwa wa, kini ṣe ti o pẹ tobẹ?"

Òbìrí-aiye ba tun dahun o ni, "Ọmọ mi, ko si irẹjẹ lọw
Olodumare, Alaṣẹ ohun gbogbo, gedegbe ni ó mã nṣe ohun
kohun ti o ba nṣe. Ki Ẹmi-Idajọ to da ẹjọ ẹbi fun ẹnikẹni o nilat
fi han gbogbo ẹda ọrun pe õtọ ni ẹni nã jẹbi. Gbogbo ẹlẹri n
yio pe jade finnifinni, bẹ̃ni ati ohun ti o l'ẹmi ati eyiti ko ní
ni o le sọrọ niwaju Olodumare. Ohun ti o jẹki o npẹ ni eyi
igi a jade a jẹri mọ ẹlomiran a ni on ni o fi ṣe kumọ ti o fi f
ẹni ẹlẹni lori, awọ a dahun a ni on ni nwọn fi ṣe ẹsẹ bata t
ọkunrin miran fi ta iyawo rẹ ni ìpá titi ti oyun fi ṣẹ́, ìṣó a ni on n
nwọn gbá mọ́ ori olori mọlẹ ti awọn ọlọṣa fi ko nkan rẹ gbogb
lọ, okùn a ni on ni nwọn fi de obinrin kan mọ igi ti nwọn f
kó ohun gbogbo ti o ni, àdá a ni on ni ọkọ kan fi ṣa iyawo r
pa, egbo igi gbogbo a ko ara jọ nwọn a ni awọn ni iyale ka
pa pọ ti o fi pa iyawo, awọn miran a ni awọn ni obinrin kạ
pa pọ ti nwọn fi yi ori ọkunrin ọlọkunrin, ata ọbẹ̀ njẹri, ẹf
njẹri, ila njẹri, ẹgusi njẹri, iyọ njẹri, alubọsa njẹri, tomat
njẹri bẹ̃ni ohun gbogbo njẹri mọ ọmọ araiye, nkan ti o njẹk
ẹjọ ẹnikọ̃kan pẹ ni yi, ọmọ mi."

Igbati Òbìrí-aiye ti fesi bayi, ko tun si nkan ti ọmọ si tu
fẹ bẽre mọ, o ba ki i, iya ọmọ nã ki i, Òbìrí tẹle ọmọ rẹ jade
bi o ti jade tan ni o fa a le ẹnikan bayi lọwọ pe ki o fi i ranṣ
si inu aiye, ẹni nã ba gbe Àdìitú le ejika o bẹrẹsi fo lọ. Igbat
o ṣe, o de eti odo nla kan ti o dabi okun ṣugbọn ti o mọlẹ gãra
ibẹ l'o ti mu Àdìitú ti o ko ẹsẹ rẹ mejeji si oke ti o sọ ọ sinu om
Igbati Àdìitú mã jade ninu omi yi, o ba ara rẹ lori ibusun r
Àṣẹ ala ni o ti nla.



# ÀDÌITÚ NFẸ IYUN-ADE

Àdìitú la ala nla yi ni Ilu Ifẹhinti nibiti o ti nṣe oku awọn obi rẹ, ko si pẹ pupọ nã ti o fi lọ si Ajedubulẹ ilu ti o ngbe.

Ṣugbọn owo rẹ pọ lọ rẹrẹ, pọ to bẹ̃ ti ó ṣoro lati ṣe apejuwe nitori mọtọ ti ó ni ko ni iye, ile ti ó kọ ko ṣẽ ka, eyiti ó rà, ko ṣẽ sọ ni iye nitori owo na ko duro loju kan, owo nwọle ṣa ni.

Àdìitú wa ni ọrẹ kan ni Ajedubulẹ ti orukọ rẹ njẹ Adémẹ̀tọ́. Bi orukọ ọrẹ yi ti ri gãn ni on nã ri. Adémẹ̀tọ́ mọ ẹ̀tọ́ lọpọlọpọ, ọrẹ ododo ni. Ọlọrun bi ì tan on nã pãpã ko lowo tabua bi Àdìitú ni, ko si ọdun ti nwọle ki ó má pa ãdọta apo ṣugbọn ãdọta apo rẹ fẹrẹ má to pọnun kan lara owo Àdìitú. Ko si jẹ jowu Àdìitú rara, ko nsọrọ rẹ buruku lẹhin, ko nfi oju rẹrin ki o yínmú si ipakọ, ki o gbe imọran ibi kalẹ ki o fi rere sabẹ ahọn. Bi ó ba ra ṣokoto kan a ra ti Àdìitú pẹlu, bi ó ra fila a ra ti ọrẹ rẹ, ibiti o ba si ti ri ọkan o ko ni ṣai ri ekeji. Nwọn dabi ahọn on ẹnu.

Adémẹ̀tọ́ wa ni aburo kan, obinrin—Ṣe ẹ mọ ilẹkẹ ti a npe ni iyùn? Bi ẹ ko tilẹ mọ ọ, ẹ jẹki nsọ ọ fun yin. Iyùn jẹ ilẹkẹ ti o lẹwa pupọ, a ko si nṣai ri i ni ile awọn ọba. Igbati iya ọmọ yi bi i, o lẹwa to bẹ̃ ti o jẹ pe orukọ ti o fi sọ ọ, o fi ti ilẹkẹ nã kun u o pe e ni Iyùnadé. Iyùnadé dara l'ọmọbinrin, ẹ̀gàn l'o ku. O pupa ròbòtò, gbogbo ara rí mìnìjọ̀, ko sanra bàkìtì lasan, bẹni kò rù han-ngogo, o ri ṣóṣóró o si ga diẹ, gbogbo nkan ti obinrin fi iwu ni ni ó ní gbogbo, ẹyinloju mọlẹ kedere, kò pupa ràkọ̀ràkọ̀ bi oju ejo. Bi enia ba wo ipenpeju rẹ o dabi ẹni pe Olodumare dá tirẹ ṣe lọtọ, ti ó tọ́ nkan dudu tẹ̃rẹ si i, ete ko fẹlẹ rekọja, bẹ̃ni ko nípọn pọ̀n-ǹ-pọ̀n, ehin funfun bi oju ọjọ, ẹsẹ ko ri tẹ̃rẹ bi ẹsẹ ọ̀gà, bẹ̃ni ko ri jàkìtì bi ti ajanakũ, ori ko ri gidigbi, ko ri palaba, ko ri gbọ̃rọ, Ẹlẹda ṣe e ni iwọntunwọnsi, o ba ọrùn mu. Bi o ba wo Iyunade niwaju, a wù ọ, bi o wo o lẹhin, a wù ọ, bi ó ba nrin a mã tẹ ilẹ jẹjẹ, a mã yan lóńgẹ́ lóńgẹ́ lọ. Bi Olodumare ti fun u ni ẹwa ara nã l'o tun fun u ni ara ẹ̀yẹ, bi Iyunade ro aṣọ adirẹ a mọ ọ lara, bi o ro

ìtẹ́kọ̀ lasan, a mọ ọ lara, àgàgà ki ó wa fi ara ba àrán tabi damãsi. A! Ọlọrun da ọmọ nã ní adape, bi ó sọrọ, a sọrọ jẽ, bi ó rẹrin, a rẹrin wẹ́rẹ́, ko jẹ sọrọ hàmù bi alaironu, ki o jẹ obinrin ki o fọhun ọkunrin, ki o mã bu hàmù bi ẹdun ori igi. Ko si nkan ti Ẹlẹda fi du ọmọ nã, ẹ tun wo o, baba rẹ̀ ri jẹ, iya rẹ̀ si ri jẹ ọmọ iya ati ọmọ baba si ni on ati Àdémẹ̀tọ́ bẽni ko si ẹniti Adémẹ̀tọ́ fẹran bi rẹ̀, ko si ohun ti ó nfẹ ti ko le ṣe fun u.

Ni ọdun keji ti Àdìitú de Ajedubulẹ ni Iyunade lọ si idalẹ, ọdun kẹrin ti o si lọ si idalẹ yi l'ó dé, akoko ti o fi wà ni idalẹ ni Àdìitú ati Adémẹ̀tọ́ di ọrẹ.

Ni ọjọ ti Àdìitú-Olodumare ti fi oju kan Iyunade ni ifẹ ti ràdọ̀ bo Àdìitú bi adiẹ ti iradọ bo ọmọ rẹ̀. Bi ifẹ ṣubu lu ni, a le dide, bi ó npa ni bi ẹmu, ẹmu le fó, bi warapa rẹ̀ ngbe ni, ó le lọ silẹ, ṣugbọn ẹniti ifẹ ràdọ̀ bo kan nkan. Ifẹ ràdọ̀ bo Àdìitú patapata ko tilẹ le ronu ohunkohun ju ti Iyunade lọ bi ẹnikan kọja firí niwaju a wo ibẹ fẹ, a ṣebi on l'o kọja bi ẹnikan nbọ lẹhin a wo ibẹ a ṣebi on l'o nbọ lẹhin. Ko si ero meji lọkan ju ero Iyùnadé lọ. O wa ṣoro fun u, enia nla ni Àdìitú, ati mã ba awọn ọmọ abẹ rẹ̀ sọrọ obinrin jẹ itiju, bẽni ọjọ keji ti ó kọ́ fi oju kan Iyunade ni Adémẹtọ lọ si idalẹ kan o si to ọsẹ kan gbako ki ó to de.

Ki Adémẹ̀tọ́ to de ṣa, Àdìitú ti ṣi nkan ṣe. On ti ni ero pe nitori owo on ti on ni ati ọlá on ti o pọ, ti o jẹ pe ohunkohun ti on ba ti sọ ní ilu ni abẹ ge, nkan ayọ patapata ni yio jẹ fun Iyunade lati ri i pe on nronu ati fẹ on o ba kọwe si i.

Nkan ti o kọ ni yi :

> Ọ̀pópó Ìgbádùn,
> Ilu Ajédùbúlẹ̀,
> Ọjọ kerinlelogun oṣu kẹjọ ni
> Ẹdegbẹwa Ọdun o le mejidinlọgọta
> Lẹhin Iku Oluwa wa.

Iyunade Temi Tõtọ,

Mo ni ọrọ kan lati sọ fun yin, mo si mọ daju pe yio dun mọ yin ninu gidigidi. Emi iba duro ki Ade (àkékúrú Ademẹtọ) de ṣugbọn mo fẹ yanju ọrọ nã ki ó to de.

Mo fẹ ki ẹ pade mi ni agogo mẹsan alẹ ọjọ marun oni, ní ọ̀kan ninu awọn ile mi, ki ẹ si sọ eyiti ẹ fẹ ki a ti pade, yala ile mi





alákànpọ̀ pẹtẹ̃si mẹwa ti mo fi igba apo kọ, tabi onímẹ́jọ ti mo fi ãdọjọ gbe dide tabi onimarun ọlọgọrun apo ni. Lẹhin nã, ki ẹ sọ iru mọto ayọkẹlẹ ti ẹ fẹ ki nfi ranṣẹ wa gbe yin, yala mọto mi kekere alapo mẽdogun tabi eyiti o tobi diẹ alapo mẽdọgbọn tabi ọkan ninu awọn ti o gun gbọlọku gbọlọku alãdọta apo gbogbo.

> Ọrọ mi ko ju eyi lọ,
> Emi ni tirẹ titi iku fi mã pa mi,
> Adiitu Olodumare.

Bayi ni iwe Àdìitú lọ, mo fẹ ki ẹ ṣe akiyesi gbogbo iwa igberaga ti o han sibẹ. Lọna kini, ko iti imọ Iyunade jù bẽ lọ o pe e ni "Iyunade temi tõtọ," lọna keji o fihan gbangba pe ọrọ ti on ni on o ba a sọ, ọrọ fifẹ ni, nitori o sọ pato pe on o sọ fun Adémẹ̀tọ́ ẹgbọn Iyunade ati pãpã o pari rẹ̀ pe on ni tirẹ̀ titi iku fi mã pa on, bawo l'ó ṣe wa mọ pe inu Iyunade yio dun wipe on mã fẹ ẹ o? Ẹ tun wo o, ilẹ nṣu ni agogo mẹje, o ni ki o pade on ni mẹsan. Paripari gbogbo rẹ̀, kini o kan Iyunade lara owo ti o fi kọle tabi ti o fi ra mọto? Gbogbo nkan wọnyi ni Iyunade ri, o si ṣe e fun Àdìitú dãdã. Ìlà kan pere ni o fi da a lohun :

> Àdìitú Ọwọn,
> Nko le pade rẹ bi o ti wi—
> Iyunade.

Ṣugbọn ẹsẹ iwe kan yi, igbati Àdìitú ri i, ṣe l'o ba idi lọ silẹ, ṣe l'o dabi igbati ẹnikan gbe e ni ogedengbe ti o na ẹhin rẹ̀ mọlẹ, ti o na amọlẹ tan ti o fa a l'ẹsẹ ti o nwọ ọ kiri. Ọkàn Àdìitú bajẹ pupọ, ati pãpã tí ifẹ ọmọ nã wa ni ori ẹmi rẹ̀, tí o si wa dabi emi pe nkan ti on ro ni igbega fun on ko ju yẹpẹrẹ loju ọmọ.

Lọjọ nã ara kan Àdìitú gógó: bi ó ba mã sọrọ si awọn ọmọ ọdọ rẹ̀ ṣe l'o nkigbe mọ wọn, o jẹun ko ṣẽ jẹ, okele ko lọ lẹnu, ko si si ẹniti ó le fi inu han ju ẹgbọn ọmọ yi Ademẹtọ ti o lọ si idalẹ ti ko iti ide.

Ni ọjọ ti Ademẹtọ mã de. Àdìitú ranṣẹ to ẽmẹwa si ile rẹ̀, ni ẽmẹwẽwa l'o si ni ki nwọn jiṣẹ silẹ pe bi o ba ti de ki o wa fi oju kan on.

Ilẹ ṣu ki Ademẹtọ to de, ṣugbọn bi nwọn ti jiṣẹ fun u, ọdọ Àdìitú l'o nbọ. Igbati o de ọdọ Àdìitú, o ya a lẹnu pe ọrẹ on ti yara rù tobẹ̀ lẹnu bi ọjọ mẹta. Wiwọle ti o wọle igbe l'ó

ke, o ni "Ha! ọrẹ mi, ṣe ko si nkan?'" Àdììtú ni, "Ko si
nkan, nkan si wà, jẹki a wọ iyãra."
Igbati nwọn de iyãra tan, Àdììtú ni, "Adémẹ̀tọ́, à ní ifẹ
ràdọ̀ bò mi sẹ." Ọrẹ bu si ẹrin o ni, "Àdììtú, ifẹ ràdọ bò ọ,
ràdọ̀ bawo?" On nã tun ni, ani ifẹ ràdọ bo mi, ko jẹki ngbe
apa ko jẹki ngbe ẹsẹ. Ademẹtọ wa bẽre wayi o ni, "Ifẹ tani?"
On nã ni, "Àní ifẹ aburo rẹ ni." "Ewo ni ninu wọn?" Àdììtú:
"O ni meji ju Iyùnade lọ?"
Ṣugbọn Ademẹtọ fẹran ọrẹ rẹ̀ yi pupọ, o si fẹran Iyunade,
o mọ pe bi awọn mejeji ba fẹ ara wọn, yio dara fun Àdììtú yio
si dara fun Iyunade pẹlu, bi nkan rere ba nbọ lọdọ Àdììtú,
Ademẹtọ kọ ni yio tãri rẹ̀ s'ẹhin ṣugbọn bi aburo tilẹ dara ju
bi Iyunade ti dara, bi iwa rẹ̀ ko ba dara ko jẹ da ori ọrẹ rẹ̀
si i. Ademẹtọ mọ anfani ti yio ti iru idapọ bẽ jade, o si pinnu
lati ran ọrẹ rẹ̀ lọwọ o bẽre bi o ba ti sọ fun aburo on bi ko ba
ti isọ fun u onitọhun ko tilẹ da a lohun ẹ̀dà iwe ti o kọ si
Iyunade ni o gbe han ẹgbọn rẹ̀.
Igbati Ademẹtọ ri i, o ba Àdììtú wi dãdã o wi fun u pe ko
si nkan ti o ko aburo on ni irira ju igberaga lọ. Igberaga iru
eyiti Àdììtú si fihan ninu iwe ti o kọ ni o ko Iyunade ni irira
ju. Ṣugbọn o ṣe ileri pe on o ran a lọwọ o si tun kilọ fun u
ki ó má da nkankan ṣe nipa ọran nã mọ láì jẹ pe o kọ sọ fun on.
Nwọn tuka lalẹ ọjọ nã, Ademẹtọ wa si ile, Àdììtú na sun si
tirẹ̀.
Igbati ilẹ ọjọ keji mọ ni Iyunade to ri ẹgbọn rẹ̀. Bi o si ti
ri i ti o ki i tan ni o bẽre ti o ni, "Njẹ ẹ ti lọ ri Ògòǹgò ọrùn?"
Ademẹtọ ni, "Tani njẹ bẹ?" Iyunade tun fesi o ni, "A, ẹ
gbọ ẹgbọn mi, ẹ ó ha ni ẹ kò mọ Ògòǹgò ọrùn ni ilẹ yi? Ọrẹ
yin! Ẹ ní meji?" Ademẹtọ ni, "Àdììtú ni mo mọ ni ọrẹ mi
pataki ni ilẹ yi." Afi Igbati Iyunade ke ti o ni, "Hãn, on nã
ni Ògòǹgò ọrùn, bẽ l'emi npe e ni temi, ẹ kò ri bi ọrùn rẹ̀ ti
gun bi ọrùn Ògòǹgò ni?" Ademẹtọ mi ori pẹlu iyanu, o gbin,
o sọ ori ṣẹ́ṣẹ́ o tun wo Iyunade lẽkan si i o ni, "Iyunade!
Iyunade! Iyunade! Hẽpa rẹ. A ó mã wo ọkọ ti o mã fẹ, ki
o mã bu gbogbo ọkunrin ṣa! Iya wọn ti o ngbọ tun dahun
si i o ni, T'aló tun nbu?" Igbati iya wọn gbọ pe Àdììtú ni,
ko le gba gbọ nitori ko si meji Àdììtú l'ọkunrin, o dara ju





ẹja inu omi. Afi igbati Iyunade tun bọ siwaju pẽrẹ o ni,
"Otọ ni mo bu u mo pè é ni Ògòǹgò ọrùn nitori ọrun rẹ̀ gùn
bi ọrun ògòǹgò loju mi." Iya rẹ̀ ni, "Iyunade! Ọrùn Àdììtú,
ọrun Àdììtú tun gun bi ọrun ogongo! Ẹru rẹ nba mi, ó ṣetan
baba rẹ ki ipẹ̀gàn, emi ti mo si bi ọ ni yi, nko bu ẹnikẹni lẹhin
ri, ki enia wipe ọrùn Àdììtú ti o dara bi egbin tun gun ju!"
Nwọn ko sọ ju bayi lọ lori ọrọ nã ni ijọ yi, Ademẹtọ ko wipe
on gbọ nkan fun aburo rẹ̀, Onitọhun nã ko si sọ pe ẹnikẹni
kọwe si on ki o to de. Inu wọn ni nwọn mọ gbogbo nkan si.
Ṣugbọn ọrun Àdììtú ko gun ju ti ẹgbẹ rẹ̀ lọ, Iyunade ra
ẽbu na fi bu u ni, ko si ibikan ni ara Àdììtú ti o kere kọja tabi
ti o tobi ju bi o ti yẹ, arẹwa gbã ni, bi awọn obinrin si ti nwa
oju rẹ̀ to ko mọ ni iba, ko fẹ wọn ni.
Enia nla ni Àdììtú ni ilu Ajedubulẹ ki isi saba jade pupọ
ẽkọkan ṣa, a mã lọ si ile ọmọ ọba nitori ọrẹ rẹ̀ ni, ẹnikan ti o
mã nwa si ile rẹ̀ ju na ni Ademẹtọ, o si to bi ọsẹ keji lẹhin
ti ọrọ yi ti ṣẹ lãrin on ati Iyunade ki o to de ile ọrẹ rẹ̀ yi, nitori
bi o tilẹ jẹ pe ojõjumọ ni Ademẹtọ nde ile on, on ni itiju pupọ
ko fẹ ki on fi oju kan Iyunade.
Igbati o di ọsẹ keji ṣa, Àdììtú lọ si ile ọrẹ rẹ̀, o ri Iyunade,
o ki i, on nã si da a lohun dãdã. Lẹhin eyi o bẹrẹsi wa sibẹ
wẹ́lẹ́wẹ́lẹ́ nitori ifẹ Iyunade kò kuro lọkan rẹ̀ rara.
Igbati o wa ni ọjọ kan ti on ati Ademẹtọ bẹrẹsi ta ayò, ti
Ademẹtọ npa a ti o npa a ti o npa a l'ayo ṣa, Iyunade ti nworan
ko mọ igbati on dá si i, o bẹrẹsi wi fun Àdììtú o ni, "Ẹ kún Òdù
yin." Ẹ na eleyi mọ ọ. "Ẹ ti eleyi si i." Ẹ ta òdù—wà,
wà, wà, wà, wà,—odu jẹ marun, "Ẹ tun gbe eleyi, ẹ jẹ kan
yi, o di lẹ̀mù." "Ẹ wa tun ta odu keji. O di lẹ̀mù, lẹ̀mù,
lẹ̀mù, lẹ̀mù—odu jẹ mẹrin." Ẹ ti ọkan yi si i. "Ẹ jẹki ọ jẹ ẹ,
hãn, ẹ wa jẹ meji tiyin—lẹ̀mù, lẹ̀mù, ẹ ko meji." Bayi ni
nwọn sa ta ayo yi, igbati nwọn le ayo Àdììtú pa. Ademẹtọ
ko mọ igbati o sọrọ jade ti o ni "Tọkọtaya l'o pa mi, ki iṣe
Àdììtú nikan."
Lọjọ keji ayo yi, Àdììtú tun ṣi nkan ṣe. Ti ayo ti nwọn ta
lọjọ yi ti mu ki o ro pe Iyunade fẹran on ati pe o fẹ lati fẹ on.
O wa fi nkan ranṣẹ si i. Ademẹtọ ti sọ fun u pe ko gbọdọ ṣe
ohunkohun nipa ọran nã titi yio fi sọ fun on, ṣugbọn ifẹ ràdọ̀

bo Àdìítú, o di aja ti ko gbọ fere ọdẹ, ifẹ ràdọ̀ bo o, ko huwa bi enia mọ, o nṣe ṣìbáṣìbo kiri lati ba fi ifẹ han si Iyunade. Nkan wọnyi ni Àdìítú fi ranṣẹ, ìgàn aṣọ àrán mẹfa, ìgàn damãsi mẹfa, ti àǹkàrá mẹfa, ti adirẹ mẹfa, ti oniruru aṣọ ẹlẹpa ni mẹfa mẹfa, ti ìtẹ́kọ̀ mẹfa, awọtẹlẹ obinrin mẹfá, pátá obinrin mẹfa, bùbá mẹfa mẹfa ti o ba orişirişi aṣọ wọnyi mu, iborun mẹfa mẹfa bẹ̃, bàtà bẹ̃, yẹri gõlu eti bẹ̃, ẹ̀gbà gõlu bẹ̃, ẹ̀wọ̀n gõlu bẹ̃ ati ohun gbogbo ni mẹfa mẹfa ṣa, o ko wọn sinu mọto nla kan o di ile Iyunade.

Igbati awọn nkan wọnyi de, inu bi Ademẹtọ pe ọrẹ on ko sọ fun on inu tun bi Iyunade nitori ko mọ idi rẹ̀ ti o fi fi nkan rẹbẹtẹ bẹ̃ ranṣẹ si on.

Iyunade tilẹ fẹ kó wọn pada fun Àdìítú ṣugbọn ẹgbọn rẹ̀ ranti pe ọrẹ on ti wi fun on bi on ti fẹran aburo on yi to.

Àdìítú ki ifi ọran nã bò fun ọrẹ rẹ̀ nigbakan, igbakigba ti o ba ti ri Ademẹtọ, bi ẹlomiran ko ba ti si nibẹ pẹlu wọn ọrọ ti yio kọ sọ ni, "Ademẹtọ, ifẹ aburo rẹ ràdọ̀ bò mi."

Ṣugbọn Ademẹtọ wi fun aburo rẹ̀ ki o kọwe ki o dupẹ ati pe ki o jẹki o mọ pe pipọ ti awọn nkan nã pọ ju ko mu inu on dun, kàkà bẹ̃ ṣe l'o mu ki on mã binu si Àdìítú

Igbati Iyunade kọwe on tun ti ṣe aṣeju ko si jẹki ẹgbọn on ri i titi ti o fi fi iwe ranṣẹ. Ohun ti o kọ si Àdìítú-Olodumare ni eyi:

> Ọjọ kẹ̃dọgbọn oṣu kẹjọ,
> Ẹ̀dẹgbewa Ọdun o le mejidilọgọta
> Lẹhin Iku Oluwa wa.

Ògòǹgò ọrùn mi ọwọn,

Iyalẹnu ni yio jẹ fun ọ lati rí bi mo ti bẹrẹ iwe mi yi, nitori orukọ ti mo fun ọ yi, Ògòǹgò Ọrùn kọ ni awọn enia fi npe ọ. Mo pe ọ bẹ̃ ki o ba mọ bi o ti jẹ lọwọ mi ni, awọn ẹlomiran ti nwọn nwa oju rẹ mọra a mã pọn ọ, nwọn a ni o dara l'ẹwa, nipa eyi, nwọn kọ́ gbe bùbá igberaga fun ọ, iwọ nã gbà, ó tun ṣe nwọn fun ọ ni dàǹṣíkí igberaga, o tun gbà, nwọn ti wa fi dàǹdógó igberaga wọ ọ l'ọrun bayi tobẹ̃ ti, ati mọ nkan ti o nṣe di ijangbọn fun ọ. Awọn ọrẹ rẹ ko jẹ sọ fun ọ bi ọrùn rẹ ti ri, awọn ojulumọ rẹ, ko jẹ fi ibatan ti o wa ni ọrun rẹ ati ti ògòǹgò han ọ. Iwọ nã gba bẹ̃ o nrin o nṣe ẹhin gán—ńkú gán—ńkú kiri.





Ki a tilẹ sọ õtọ nả, Àdìítú, Kini emi rẹ fà pọ ti o fi wa fi gbogbo nkan rẹbẹtẹ wọnni ranṣẹ si mi? Lẹhin eyini, ki tun ni idi rẹ̀ ti o fi fi gbogbo nkan ranṣẹ ni mẹfa mẹfa bi ẹni pe o npa owe si mi pe iwọ fẹ fa mi mọra, iwọ wá npowe si emi o! Si mi o! Adiitu, pe mo le fẹ ọ ni ọjọ iwaju! Emi si ọ, si iwọ Àdìítú? Ṣé bẹ̃ nã l'o kọwe ki nwa pade rẹ ni agogo mẹsan oru ni ijọsi? Mo fẹ wi fun ọ, owo rẹ ko jẹ nkankan si mi, ki o ba ọ, ki o ba mọto gbọlọku ki o ba igan aṣọ aran mẹfa.

Bi o ba fẹ fun mi ni nkan gẹgẹ bi ọrẹ ẹgbọn mi, mo gbọ, bi o ba ṣe mi ni alejo ti ko ni igberaga ninu, mo gbà, ki a wipe agolo àtíkè kan pere l'o ra wa fun mi, ò ba ri i bi o ti mã ni iyi to lọwọ mi, ṣe ni mba gbe ọ soke kẹ-nkẹ. Maṣe gbagbe lailai, Adiitu Olodumare, pe ko si nkan ti o bi Olodumare ninu ju igberaga lọ, irira ni loju Ọlọrun, ohun ikọsilẹ ni loju awọn anjọnnu, bẹ̃ni gbogbo irunmalẹ ode aiye l'o korira igberaga jakejado bamubamu.

> Ọrọ pupọ, irọ l'o nmu wa,
> Ọrọ mi ko ni gun gbọlọku bi mọto rẹ,
> Emi ki iṣe tirẹ nitõtọ.
> Iyunade.

Bayi ni iwe ti Iyunade kọ si Àdìítú lọ. Igbati Àdìítú ka a dãdã, ko binu, iwe ti ó tilẹ tun fi fesi fi ọgbọn han gbangba, bayi ni iwe nã lọ:

> Òpópó Ìgbádùn,
> Ajédùbúlẹ̀,
> Ọjọ kẹdọgbọn Oṣu keji, ẹ̃dẹgbẹwa
> Ọdun o le mejidilọgọta
> Lẹhin Iku Oluwa wa.

Iyunade mi ọwọn,

Mo dupẹ pupọ fun iwe rẹ ti mo ri gba loni, mo dupẹ gidigidi. Ó kọ ya mi lẹnu lati ri i pe ẽbu l'o fi bẹrẹ iwe nã, ṣugbọn igbati mo tun ronu diẹ ko bi mi ninu ju bẹ̃ lọ mọ.

Lọna kini, pípè ti o pe mi ni "Ògòǹgò Ọrùn" fi han pe ọmọ rere gbã ni ọ nitori o fi han pe bi nkan ba ti ri l'ọkan rẹ l'o mã nsọ. Ati pãpã, mo ri i daju pe bíbú ti o bu mi, o fẹ fi wẹ iwa igberaga ti o ṣebi ó wà ninu mi ni, ki iṣe pe o bu mi lasan. Emi ka a si nkan pataki pe ki obinrin ẹni le sọ õtọ fun ni bi o ki wu ti õtọ nã koro to, ki a l'obinrin ki a le gbẹkẹle e, eleyi dara lọpọlọpọ.

Iwọ pãpã sọ ní pàtó pe ki a wipe mo fun ọ ni nkan kekere iba dun mọ-ọ ṣugbọn, Iyunade, ki iṣe pe mo fi gbogbo nkan ti mo ti nṣe ṣika si ọ. Idi rẹ̀ ko ju pe mo fẹran rẹ gidigidi. Ṣugbọn

kini kan ni, iwọ gãn l'o fi ẹnu ba pe a fẹ ni tabi a ko fẹ ni ki iṣe emi l'owipe mo mã fẹ ọ, nko kọ ọ sinu iwe si ọ, nko si yan enia ki o ba mi ba ọ sọrọ. Sibẹsibẹ nã, imọran mi fun ọ ni pe ki o rọra mã sọrọ, nitori ọjọ iwaju. Lõtọ, o l'ẹwa pupọpupọ, lẹhin nã o tun ní ọgbọn ori, paripari gbogbo rẹ, awọn obi rẹ jẹ ẹniti o yẹ ki enia fi ṣe ànà, nitori nwọn ko bà ọ jẹ rara nwọn sun ọ jina korokoro, nwọn ko si jẹ fi ọ si ìkọ̀kọ̀ ki o ba ri aye hu iwa wọbia, ki nwọn mã ṣe atílẹhin ohun buruku fun ọ. Ṣugbọn sibẹsibẹ, leri gbogbo anfani wọnyi ti Ẹlẹda fi jinki rẹ, o ko lagbara bi Olodumare, nitorina oni l'o lè mọ̀, o ko le mọ ọla, bi iwọ ba wipe o ko le fẹ mi ti Olodumare wipe dandan emi l'o mã fẹ nkọ? Ki l'o le ṣe?

Ni ipari gbogbo ọrọ mi, mo dupẹ pupọ fun iwe ti o kọ ati ọgbọn ti o kọ mi ninu rẹ ng o fi i si ọwọ osi ki nmá ba fi ọwọ nã jẹun.

Emi ni tirẹ nitõtọ,
Àdìitú-Olodumare.

Esi ti Àdìitú fun Iyunade ni yi. Igbati Iyunade si ka a, iyalẹnu l'o jẹ fun u. Sibẹsibẹ, obinrin ko ni ṣai ṣe obinrin, esi ti o fun Àdìitú, bibu nã l'o tun bu u, ko kọ ju eyi lọ.

Àdìitú Ọwọn,

Mo dupẹ lọwọ rẹ iwe ti o kọ, ṣugbọn mo fẹ ki o mọ pe Olodumare kò gọ̀ bi iwọ, kò jẹ fi mi fun enia bi rẹ. Bi ó ku iwọ nikanṣoṣo ninu aiye, a jẹ pe kiku ni mo mã ku láì ni ọkọ.

Emi ni tirẹ nitõtọ,
Iyunade.

Iwe bayi ni on tun kọ, Àdìitú ko fesi pada mọ ṣugbọn Iyunade nikan ni ọkan rẹ ko balẹ ti o bẹrẹsi rọra yọ kẹlẹkẹlẹ lọ wo nkan. Ó lọ si ile babalawo, onitọhun da ifa fun u, nitori ogunlọgọ enia l'o nfẹ ẹ o si ti di ọmọ ọdun mẹrinlelogun, ko tilẹ darukọ Àdìitú rara ṣugbọn nigbati ẹniti o da ifa mã ṣe apejuwe ọkọ ti o mã fẹ, o dabi ẹni ti o jọ Àdìitú diẹ, ṣugbọn ko jọ ọ dãdã, o tun lọ wo yanrin, ẹniti o wo yanrin fun u ko sọrọ kan ẹniti o jọ Àdìitú, o lọ wo irawọ, onirawọ na ko ṣe apejuwe Àdìitú, o wo ọwọ, ọrọ ti ẹniti o wo ọwọ sọ ko ye ni. O wa lọ si ọdọ ọkunrin kan ti o ngbe inu igbo ti ori rẹ kùn gẹlẹti bayi nwọn ni ọjọ mẹdogun l'oṣu ni ọkunrin nã fi igbãwẹ, o si ti sunmọ obinrin mọ, ọjọ gọ, agbalagba patapata ni, oju rẹ ti jin wọ inu eleyi ṣe apejuwe ẹniti o jọ Àdìitú diẹ, ṣugbọn ko darukọ ẹnikẹni. Nikẹhin Iyunade pinnu ati rọra dakẹ rẹ





ki ó má wo ohunkohun fun ọkọ fifẹ mọ nitori gbogbo nkan ti nbọ niwaju ni Olodumare fi pamọ fun ọmọ araiye.

Àdìitú ko ye wa si ile ọrẹ rẹ Ademẹtọ, igbamiran a ri Iyunade, igbamiran ko ni iri i. Nwọn ki iṣe ọrẹ nwọn ki isi iṣe ọta. Ṣugbọn, inu obinrin jinlẹ lọpọlọpọ, ibu omi okun ni, isalẹ rẹ ṣoro lati mọ, nitori nkan ti o ba ro pe nwọn nro kọ́ ni nwọn nro, eyiti o ba ro pe nwọn o ṣe kọ ni nwọn mã ṣe, iba diẹ ninu wọn si ni enia le gbẹkẹle nitori ẹniti o ba ro pe nwọn ko fẹ ni nwọn nfẹ, eyiti o ba ro pe nwọn mã ṣe ni nwọn ko ni ṣe. Igbamiran bi Àdìitú ba lọ si ile Ademẹtọ bi ó ki Iyunade, imu ni Iyunade yio fi dahun, igbamiran ti o ba si gbọ ti awọn mejeji ba nrẹrin, ha! ha! pọ bayi, o ó wipe nwọn ti di tọkọtaya.

Kini kan wa ṣẹlẹ lọjọ kan bayi. Àdìitú sọ lalẹ ọjọ nã pe ki ọrẹ on, Ademẹtọ mã reti on ni owurọ ọjọ keji ni nkan bi agogo mẹwa fi diẹ kọja.

Ki ilẹ to mọ ni ọjọ keji yi ni Iyunade ti ji ti o ti wẹ, bẽni ki isaba tete ji ni owurọ. Igbati o si wẹ tan ti o bẹrẹsi ṣe itọju ara, akoko ti o lo lọjọ nã gun ju ti ọjọ kọjọ lọ. Ọtọ ni o fi nkan ra oju, ọtọ ni nkan ti o tọ si ipenpeju, ẽkan ọwọ, ẽkan ẹsẹ, o tun ṣe ṣe o tọ si ete, o tọ si ahọn, o gbe to wakati kan niwaju digi ti o nyẹ ara rẹ wo. Igbati o si wa mã ro aṣọ, aṣọ ti o ro, àrán funfun ni, o funfun bálâú, ṣugbọn o fi nkan funfun wu ni, o dara pupọ.

Igbati Àdìitú pãpã mã wọle, bi ẹni pe nwọn ti sọ fun ara wọn tẹlẹ ni. On wọ ẹwu damãsi ti àwọ̀ rẹ fi ara we aṣọ alaro, nwọn da a ni gbárìyẹ̀, ó kún dãdã, o tun wọ ṣokoto damãsi nã si i, o wa lọ de fila eleti aja aṣọ damãsi yi, o ta eti fila rẹ ha-nha, o tun fi agogo ọwọ rẹ ti nwọn fi gõlu ṣe si ọwọ osi, o wọ salubata ti a kan ti o yi ẹsẹ po, oju ti o wo Àdìitú ko wo oko, ko si ọkunrin ti o le ko Iyunade lọna ti ko ni wo o lẹ̃meji ni ọjọ ti a nwi yi, ko si si obinrin ti o le ri Àdìitú ti ko tun ni wo o lẽkan si i, nitori awọn mejeji wọnyi, arẹwa patapata gbã ni wọn.

Igbati Àdìitú mã wọle o pade Iyunade lẹnu ọna. Nkan ti Iyunade si fi mã ki i ni ọrọ ti o sọ ti o ni, "Nwọn wa ni agbala." Eyini ni Ademẹtọ. Igbati Àdìitú nlọ si agbala ti o rin diẹ o

tun ronu pe ki on wo Iyunade lẹ̀kan si i, oju ti o yi pada bayi, àṣẹ́ ṣe ni Iyunade nã nwo o lọ, ṣe lóju awọn mejeji pade. Adiitu rẹrin Iyunade mọ ọ loju.

Nkan ti Ademẹtọ nṣe ni agbala gba wipe ki alejo rẹ̀ yi joko ti i. Ṣugbọn Iyunade wọ agbala nã to ẽmẹwa lẹhin eyi, bĩ o ba de a ni on nwa àwo kan, bi o tun ṣe a ni on nwa iyọ, bi o tun ṣe a ni on nwa oguro, ọpọlọpọ igba ni Àdììtú nilati dide lori aga ti o joko le nibiti Iyunade ti nwa nkan ti o nwa. Ademẹtọ pãpã, bi ẹni pe o nfẹ fun awọn mejeji l'aye gãn pe ki nwọn mã sọrọ si ara wọn lọjọ nã l'o ri, nitori ọpọlọpọ igba ni on nã njade ni agbala ti a ni on nfẹ lọ mu nkan ninu iyara bi o ba ti ri i pe aburo on de.

O wa ṣe, Ademẹtọ gba fila Àdììtú ti ó dé wò, o wọ iyãra lọ o ni on fẹ lọ fi wọn ti on kan ti on ṣẹṣẹ ra ninu apoti. Ibiti Iyunade ti ntu ile ka, o gbe iṣãsun ọbẹ o ṣi i sílẹ, o wa fẹ gbe ògì ẹkọ ninu ikoko nla kan ti nwọn gbe le ori pẹpẹ, o ngbe ikoko yi ko ṣẽ gbe fun u, o dabi ẹni pe ọwọ rẹ̀ ko to o, ni Àdììtú ba gbe okuta kan wa ti o ni ki Iyunade bọ si ẹhin on ki on ba a gbe ogi, Iyunade ba duro si ẹhin rẽ, ikoko ọbẹ̀ ti nwọn ṣi silẹ wa lẹhin Iyunade, bi Àdììtú ti gbe ẹsẹ le okuta ti o fa ikoko leti ṣe ni okuta ti o gbe ẹsẹ le yẹ̀ gẹ̀rẹ̀, ikoko ògì ṣí bo Àdììtú lori pẹlu ògì, ti o de Adììtú ni fila. Ṣe ó si yẹ ki Iyunade ran Àdììtú lọwọ, irọ, ẹrin l'o bu si, ibiti o ti nrẹrin o ta gẽgẽ sẹhin, iṣãsun kọ ọ l'ẹsẹ, o di wọ̀mù ninu iṣãsun, Iyunade ṣubu. Igbati o dide gbogbo idi rẹ̀ pọn ṣũ, aṣọ aran funfun ti o ro di pupa. Bi Àdììtú ti nwa ọna ati ṣi fila ikoko ogi ti o de kuro ni ori ni Iyunade nyọ idi ara rẹ̀ kuro ninu iṣãsun ọbẹ. Igbati o wo idi on bi o ti pupa ṣũ, ti oju ti i nitori Àdììtú bẹrẹsi rẹrin, àbàrá l'o ko bo Àdììtú o di mọ̀tì mọ̀tì, mọ̀tì. Igbati Àdììtú kò bikita ti o sa nwo o loju Iyunade fa oguro yọ. Igbati o lẹ meji mọ Àdììtú lẹhin, Àdììtú fi ire si i, Adamẹtọ ti o ngbọ kìtìkìtì ija nsa bọ ni agbala o pade Àdììtú lọna nwọn fi aiya gba aiya, o di wò-ǹ-gàngàn, Ademẹtọ ṣubu lulẹ, Àdììtú tọ ori Ademẹtọ siwaju, Iyunade sá tẹ Ademẹtọ lori tẹle Àdììtú o nle e lọ, igbati Àdììtú ni ki on jade patapata ninu ile o pade iya wọn agba lọna, ó di gbẹ̀, iya ṣubululẹ, awọn mejeji yi ko tilẹ sọ pe awọn ri i, ṣe ni nwọn tubọ nle ara wọn lọ. Ṣugbọn oke kan bayi





ko jina si iwaju ile awọn Ademẹtọ, oke nã ga bi enia ba si gun u de oke tan odi keji rẹ̀ tun jẹ ìdàgẹ̀rẹ́ gẹ̀rẹ́ lọ si isalẹ titi o fi lọ kan odo kan bayi. Bi Iyunade ati Àdììtú ti ṣe le sare gun oke yi ya ni lẹnu, nwọn sare gun u tõtọ ṣugbọn bi nwọn ti de ṣonṣo oke ni Àdììtú pade awọn ọmọbinrin pupọ ti nwọn gbe akengbe le ori ti nwọn ngun oke bọ lapa ọhun, pipade ti o pade wọn ti o duro ṣi, Iyunade ti ko mọ tẹlẹ ti o fi dede duro ṣubululẹ lapa ọhun on yi gbirigbiri pada lọ, ibiti Àdììtú si ti nsa ki on má kọlu awọn ero odo ẹsẹ rẹ̀ yọ́ tẹ̀rẹ́, o di ilẹ, o kọlu ẹnikan, ẹnikan kọlu ẹnikeji, ẹnikeji kọlu ẹnikẹta ati Àdììtú ati gbogbo wọn ṣubululẹ nwọn nyi gbirigbiri lọ. O wa jẹ pe Iyunade nyi lọ si isalẹ oke lapa ihin Àdììtú nyi lọ lapa ọhun. Igbati Àdììtú yí de isalẹ, ile rẹ̀ l'o ba lọ.

Ṣugbọn igbati Iyunade yí de isalẹ lapa ihin o tun bẹrẹ ire o tun gun oke de ori, igbati o de ọhun ko ri ẹniti ó nle mọ, sibẹ o nsa kiri, o nwa Àdììtú ka, ibiti o ti nṣe eyĩ afi igbati ọmọbinrin kan sa jade, ko ju Iyunade lọ, on lọ jale, awọn ti ó jí ni nkan nle e bọ. Bi o ti ri Iyunade o sa si kọrọ kan, awọn ti o nle e bọ ko ri i mọ Iyunade ni nwọn ri ti o nsa, nwọn ba bẹrẹsi le Iyunade lọ. On ko mọ nkan, o sa ngbọ girigiri ẹsẹ bọ lẹhin ni, afi igbati o pẹ ti nwọn ba a ti nwọn bẹrẹsi lu u, ti nwọn fi okun si i l'apa ti nwọn dè é sẹhin ti nwọn wa gbe aṣọ le e lori, o di ile ọlọpa. "Kini mo ṣe, kini mo ṣe?" ni Iyunade nke titi nwọn fi mu u de ile Ọlọpa ti nwọn bẹrẹsi ro ẹjọ pe o wa jale ni ile awọn ni awọn ba mu u.

Igbati Ọlọpa bẽre lọwọ Iyunade ko le ri sọ ju pe on ati Àdììtú ni awọn nle ara awọn ka, o wo wa o wo ẹhin o wa Àdììtú tì ko ri Àdììtú, ọran wa di, "Àdììtú da? Àdììtú da? Ẹ jọwọ ẹ ba mi wa Àdììtú lọ, ẹ sa jọwọ ẹ ba mi wa Àdììtú lọ, emi ati Àdììtú la jọ nṣire, Àdììtú o : — : — : — o, Àdììtú o : — : — : — o, Àdììtú o : — : — : — o.

Awọn ọlọpa ba ran ẹnikan ki o wa Àdììtú lọ, Àdììtú ki ikuku ṣe ẹniti awọn nã ko mọ ṣugbọn igbati nwọn jiṣẹ awọn ọlọpa fun Àdììtú ti ẹniti o jiṣẹ si tun sọ pe ibẹ ni Iyunade wa, Àdììtú ṣebi o pe on lẹjọ ni, o ba ranṣẹ si awọn ọlọpa pe on ko wa, pe ẹjọ nã, ẹjọ ti awọn le pari ninu ile ni.



' Bi o ti de ibẹ ni gbogbo awọn ọlọpa nã ti nki i '





Igbati nwọn jiṣẹ bayi, werewere ni Iyunade ni ki nwọn ba on wa iwe kan ki on kọwe si Àdììtú. Bi nwọn ti mu iwe de ti o ri nkan ikọwe gbogbo, iwe didun ni o kọ si Àdììtú werewere, tani njẹ́ ẹ, ohun ti o kọ ni yi.

Ile Ọlọpa
Ajedubulẹ,
Ọjọ kẹtadilọgbọn oṣu kẹjọ
Ẹdẹgbẹwa Ọdun O le mejidilọgọta
Lẹhin iku Oluwa wa.

Àdììtú temi ọwọn,

Ire ti a jọ nṣe lẹ̀kan, nwọn mà ti mu mi o. Ile ọlọpa ni mo wa bayi, jọwọ wa gbà mi o

Emi ni tirẹ,
Iyun (IYUNADE)

Bi iwe yi ti tẹ Àdììtú lọwọ ko tilẹ duro ki dẹrẹba·on wa on, were l'o gbe mọto ayọkẹlẹ gbọlọku kan si ọna o di ile ọlọpa. Bi o ti de ibẹ ni awọn ọlọpa nã ti nki i, "Ẹ kabọ, ọga" igbati Iyunade si ti wipe ki o sọ nkan ti on mọ nipa lílé ti on nle on, ti o sọ ti tirẹ̀ ko si yatọ si ti Iyunade, awọn ọlọpa gba pe nwọn ṣeṣi mu Iyunade ni, pe ki iṣe on l'o jale, nwọn ba da a silẹ ki ó mã lọ.

Igbati Iyunade kuro lọdọ awọn ọlọpa ṣe l'o rọra ba ile rẹ̀ lọ. Àdììtú tilẹ sọ fun u ki o jẹki on fi mọto gbe e de ile ṣugbọn ko gba.

Igbati Iyunade fi mã de ile o to wakati mẹta ti o ti le Àdììtú lọ ṣugbọn awọn ara ile ko tilẹ gbọ pe nkankan ṣe. Gbogbo wọn ni nwọn pọ oró si ẹnu de on ati Àdììtú nitori ìyá ti nwọn kọlu lẹnu ọna daku, ṣe ni nwọn pe e, pe e, pe e, ki o to ji. Igbati Iyunade wa ro gbogbo ọran nã lati ilẹ ni pupọ ninu awọn ara ile to mọ nkan ti o ṣe.

Ẹrin ni Ademẹtọ fi wọn rin o ni, "B'o ti ṣe yin l'o yẹ k'o ṣe yin, afi 'pakọ mi t'o wu t'o yọ gọmbu". Ko si ẹniti ko fi ara pa ninu ọran yi, iya ti o ṣubu, iya fi apa da apa ko ṣẽ gbe, Ademẹtọ ti o fi pakọ na ilẹ, ipakọ wu, ipakọ yọ gọmbu, Iyunade ti o nle Àdììtú kiri fi ẹsẹ da o nrin yẹ́rẹ̀kú yẹ́rẹ̀kú. Àdììtú tí ikoko yí bò lori fi imu bo, o ngbe egbo kiri ni imu.

O pẹ diẹ ki Àdììtú to tun de ile Ademẹtọ nitori imu rẹ̀ ti o fi bo ko tete san, igbati o si san tan o funfun, ko tete dudu.

Nitori eyi, ko fẹ gbe imu rẹ de ile Ademẹtọ o ni :
"Iyunade yan ìpátá pupọ ko ni ṣai pe oluwarẹ ni onimu-funfun."

Ṣugbọn lati igbati ọran yi ti ṣẹlẹ ni ara Iyunade ko ti le, Ademẹtọ ko si fẹ sọ fun ọrẹ rẹ, nitori aburo rẹ pẹlu ọrẹ yi ni nwọn jọ nle ara ka ti ijangbọn fi ṣẹlẹ, ṣugbọn ìlò ti awọn ti o mu u l'ole lò o ki ọlọpa to da a silẹ ko dara nwọn lu u pupọ ki isi iṣe ọmọ ti ìyà kan jẹ ri.

Bi ire bi ire aisan yi ndi nla, Iyunade rù ó kù han-ngogo, ko kuku sanra pupọ tẹlẹ, bi enia ba si wo o bayi, gbogbo ẹwa ara rẹ ti tan patapata, gbangba ni enia nwo egungun apa ati egungun ẹsẹ, enia le mọ iye iṣan ti o wa ni ọrun Iyunade, enia le ka iye ẹfọn ìhà, enia mọ gbogbo ibiti egungun oju ti pade ti eti, ti ti eti ti pade ti imu ati ibiti egungun àgbọ̀n oke ati ti isalẹ wà gãn, ko si ẹran lara mọ, iba ẹjẹ diẹ l'o ku bi ó ba si fẹ rin bayi, bi ẹni mã ṣubu bi ẹni mã ṣubu ni.

Ko si babalawo ti ko de ibẹ tan ko si Adahunṣe ti nwọn ko pe, igbati o ṣe ṣa nwọn sọ fun Àdììtú pãpã, on l'o damọran pe ki nwọn lọ pe Dokita kan ni nwọn ba pe e. Ni owurọ ọjọ kan bayi ni Àdììtú bẹrẹsi gbọ igbe ọrẹ rẹ ti o nke bọ ni ile rẹ. "Ogun o! Ogun O! Ogun O! Ogun mu mi o! Ogun mu mi O! Ogun mu mi O!" Iyunade l'o daku. Ni Àdììtú ba sa jade o di ile Ademẹtọ. Gbangba bayi si ni Dokita nã wi fun Ademẹtọ pe on ko ro pe Iyunade le ye mọ, ó nilati ku ki o tilẹ to di alẹ ni.

Gbogbo enia l'o bẹrẹsi sọkun ṣugbọn Àdììtú ko sun, inu l'o bẹrẹsi rò.

Àdììtú mura o di ile, o de ile rẹ, o bọ si iyãra, o bọ gbogbo aṣọ ara, ko si nkan ti o kù si i lara mọ o dọbalẹ gbalaja niwaju Ẹlẹda rẹ o ni 'Olodumare, iwọ Ẹlẹda mi, o ko jẹki ntẹ́ ni ode aiye yi ri, jọwọ má jẹki ntẹ́ o, Ẹlẹda mi, mo ti gbe ẹbọ kọja orita, mo ti fa jangbọn l'ẹsẹ mo ti fa ra mi sinu ọgbun, kini ki a ti gbọ ọ? Olodumare, kini ki a ti gbọ ọ, ki a wipe mo ni ọwọ si iku aburo ọrẹ mi? Aburo Ademẹtọ nikan ti o fẹran mi julọ ni 'lẹ yi? A! Jọwọ Olodumare gba mi ninu ọran ilẹ yi, Ọba Onibuọrẹ, gba mi ninu ọran yi, Alèwílèṣe, gbà mi ninu ọran yi, Ẹlẹda mi, gba mi ninu ọran yi, Ẹni Àìrí, gba mi





ninu ọran yi, Ologo julọ jọwọ maṣai gba mi, Alafẹhinti, jọwọ maṣai gba mi, Ọlọjọ Oni, jọwọ máṣài gba mi, Ẹni Mimọ, jọwọ maṣai gba mi, Ẹni iyanu, Jọwọ maṣai gba mi, Olupilẹsẹ, gba mi dandan, Ẹni Iṣãju, gba mi dandan, Ẹni Ikẹhin gba mi dandan, Ẹnit'o l'aiye gba mi dandan, Ẹnit'o ni ọrun, gba mi dandan, gbogbo aiye npe Ọ O ngba wọn, Onigbagbọ npe Ọ O ngba wọn, Onimale npe Ọ, O ngba wọn Oniṣango npe Ọ O ngba wọn, ọlọya npe Ọ O ngba wọn, gbogbo awọn abọriṣa sa npe Ọ O ngba wọn, temi ti mã jẹ Ọlọrun mi, Ọba mi, Olugbala mi, ti O kò ni fi gba mi o?"

Bayi ni Àdììtú sọ ti o ke si Ọlọrun Ọba, bẹ̃ni Olodumare ko fi ẹniti o ba pe E silẹ ri, O da Àdììtú lohun ni werewere.

Bi Adiitu ti fẹ jade l'ó ranti pe on gbọ pe Dokita kan tuntun ṣẹṣẹ de si Ajedubulẹ ati pe Dokita nã mọ iṣẹ pupọ pe ko si meji iru rẹ ni agbegbe nã. O ba gbe ọkọ̀ o di ile rẹ. O de ọdọ Dokita, onitọhun gba lati lọ ṣugbọn epo ti tan ninu mọto rẹ, were ni Àdììtú gbe e sinu tirẹ o di ile Ademẹtọ.

Igbati Dokita de ibẹ o ni o ku wakati mẹta pere ti Iyunade le gbe mọ lori ilẹ aiye on nilati mu ẹrọ kan ti nwọn ti ṣe bi ọkàn ki on fi dipo ọkàn Iyunade ki on ba ri aye la ọkàn Iyunade ti ko dara. Bi on ba pari iṣẹ nã ki wakati mẹta to pe a jẹ pe Iyunade ko ni ku, ṣugbọn bi on ko ba pari rẹ o nilati dakẹ ni. Gbogbo enia duro nwọn nwo ohun ti Ọlọrun mã ṣe.

Igbati o di wakati meji-abọ Dokita mi kanlẹ, o ti pari iṣẹ, o mu ẹrọ kuro nibiti o fi ẹrọ si, o fi ọkàn Iyunade gãn si ibiti o wa.

Ati igba yi ni ara ọmọ nã ti bẹrẹsi le. Igbati o mã to oṣu kan, ara rẹ ti le patapata. Ẹwà Iyunade wá tun pada, afi bi ẹni pe Olodumare sọ aisan nã di ọṣẹ ti o wẹ ara rẹ nù finnifinni. Oju ti o wo Iyunade kò wo oko, o nda gbọ̀dọ̀, o pọn ròbòtò, a rin jẹ̃ jẹ̃, a sọrọ jẹ̃ jẹ̃, Olodumare fi ọla han si i lara.

Igbati ara Iyunade to le l'o to mọ nkan ti Àdììtú ṣe fun on nitori Àdììtú fi nṣe eto ti Dokita Iyunade ko mọ igbana rara ko mọ ẹnikẹni. Ṣugbọn igbati nwọn rohin fun u, o dupẹ lọwọ olõre rẹ dãdã. Ati igbanã ni gbogbo enia si ti nṣe akiyesi pe Iyunade nfẹran Àdììtú si i. Kini kan l'o sa ti jọ gbogbo

aiye loju. Nisisiyi, Iyunade ti di ọmọ ọdun mẹrinlelogun Àdììtú si ti di mejidilọgbọn sibẹ ko si ẹniti o ni ekeji ninu wọn. Iyunade ko fẹ ẹnikẹni, gbogbo awọn ti nwọn nfẹ ẹ l'o nkọ̀ fun, Àdììtú nã ko fẹ iyawo, gbogbo awọn obinrin ti nwọn nyi i po, ko wipe on ri wọn.

Ṣugbọn kini kan wa ni, ìpátá ọmọ ni Iyunade. Ìpátá ọmọ sa yatọ si ọmọ buruku. Ìpátá ni ẹniti o le sọ nkan lọna kan ti ẹnikẹni ko jẹ sọ ti o si le huwa ti ẹnikẹni ko jẹ hu ki iṣe pe iwa nã buru, nitori ati huwa bẹ̃ nilati ti enia loju ni.

Ìpátá Iyunade ko fi i silẹ, ẹ ò si tun gbọ nkan ti o ṣe.

Àdììtú wa si ile wọn ni ọjọ kan o sọ Ọjọ Ibi rẹ̀ fun Ademẹtọ pe on fẹ ṣe ariya rẹ̀. O da oṣu kan. Bi o ti dakẹ ni Iyunade dahun ti o ni, "Ṣe ẹ́ jẹk'a ba yin ṣe ọjọ ibi o, tabi k'á má wa?"

Ṣugbọn inu Àdììtú nilati dun bi o ba wa ni, pẹlu ayọ, l'o si fi dajọ fun u pe inu on o dun bi ó ba wa.

Inu Ademẹtọ pãpã dun pe ki Iyunade ba Àdììtú ṣe ariya nã, lọna kini, Àdììtú ti ṣe nkan fun Iyunade pupọ bi ó bá bá a ṣe ariya nã yio fi Iyunade han bi ẹniti o mõre, lọna keji, Ademẹtọ pãpã nfẹ ki Àdììtú di àna on nitori ifẹ ti o ni si i.

Ha! Ìpátá Iyunade pọ, ki ọjọ ariya to pe o ti wa awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin lọpọlọpọ jọ, olukululuku si ti bẹ́ paṣan àtòrì ti oko wa, egúngún kan ti o wà ni ile wọn ni Iyunade ní ki nwọn ba on mu jade lọjọ ariya yi. Ademẹtọ ti ji kuro ni ile o lọ si ọdọ Àdììtú, nwọn si ṣe eto nã ni aṣīri tobẹ̃ ti ati on ati Àdììtú ko gbọ nkan kan.

Nigbati o to agogo mejilã ni egúngún jade Iyunade mu paṣan lọwọ, gbogbo awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin ti Iyunade ti bẹ̀ tẹlẹ nã mú paṣan. Egúngún mu tirẹ̀. Iyunade ti bẹ onilu ti yio lu tẹle egúngún, Iyunade ati ilu ni nwọn ndá orin ti awọn iyoku ngbè é, igbati Iyunade ati ilu ba wipe:

"Iyunade mbọ lọna," awọn yoku a dahun nwọn a ni "Ògòǹgò ọrùn paramọ." Bayi ni orin na wa ṣe lọ:

*Iyunade ati ilu:* Iyunade mbọ lọna
*Awọn Yoku:* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu:* Iyunade mbọ lọna





'Iyunade mbọ lọna, ògòngò ọrùn paramọ́'

*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Werewere paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Gìdìgìdì paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò Ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Apá nla paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Idi jọ̀bọ̀tọ̀ paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Iyunade mbọ lọna
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Gbe 'Yan nla paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Àt'àkàṣù bàm̀bà paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Gb'awo iręsi paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* At'ọbẹ àtàtà paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Hé è hé è paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Háà háà paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Hùn hùn paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Pẹ̀lẹ́ pẹ̀lẹ́ paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́
*Iyunade ati ilu :* Yara yara, paramọ́
*Awọn Yoku :* Ògòǹgò ọrùn paramọ́

Lõtọ o le dun Àdììtú diẹ nitori o ti bu u bẽ̩ ri, ṣugbọn sibẹ o tọju gbogbo awọn ti nwọn jọ wa, o tilẹ gbe ẹmu fun egúngún





Iyunade, nwọn bu ẹmu nã si àwo ni egúngún ba da ẹnu de e lati inu àwọ̀n ti o bẹrẹṣi fa ẹmu fin-ìn, awọn ti nwọn wa nibẹ tilẹ bẹrẹsi ṣe yẹ̀yẹ́ nwọn ni, "Ara ọrun kìnkin, ẹ nmu ẹmu lọrun dan ?" Egúngún fi ohun rẹ̀ dahun o.ni, 'A nmu u dãdã'. Igbati ẹnikan tilẹ da àpárá ti o ni, "Ṣe anjọnnu ni ndá ẹmu fun yin." Egúngún tun dahun o ni, "Anjọnnu ni yio da ẹmu fun ori rẹ mu." Adììtú kẹ wọn dãdã. Inu nbi Ademẹtọ ni isalẹ ọkan rẹ̀ o fi ohun gbogbo sinu. Igbati Àdììtú tilẹ pe e ti o ni, "Ṣe iwa ti aburo rẹ nhu yi dara ?" Ṣe l'o mi ori ti o ni, "Má sọrọ rara, fi gbogbo ija fun mi ja."

Igbati o ṣe, Iyunade mu egúngún rẹ̀ pẹlu awọn ìpátá ọmọ gbogbo ti ó kó wa lọ. Ademẹtọ ko iti ikuro lọhun. Igbati Iyunade de ile, ti ẹ̀gbọn Ademẹtọ, Àgbà-ìyà, gbọ orin ti awọn ti nwọn nlu ilu ati awọn ti njo nkọ, o ranti ṣa pe on gbọ nigbakan ti Ademẹtọ nda Iyunade 'lẹkun ki o yẹ bu Àdììtú ni "Ògòǹgò ọrùn," ko ranti dãdã, o wa duro ki Ademẹtọ de.

Igbati Ademẹtọ fi mã de ilẹ ti nṣu, o to nkan bi agogo mẹjọ alẹ. Igbati o si de ti Àgbà-ìyá bẽre bọya Àdììtú ni Iyunade kọrin bu bọya on kọ ti Ademẹtọ wi fun u pe Àdììtú ni, ko ṣe nkan kan ṣe l'o wọ ile rẹ̀ lọ ti o joko si õdẹ ti o ni ki nwọn pe Iyunade fun on. Ṣe owe awọn agba nã ni eyi pe ọmọ bọ lọwọ nínà o ku àwòmọ́jú itumọ eyiti o jẹ pe bi ọmọde ba ti ni ọjọ ori to igbakan, ko yẹ ki enia nà a mọ, bi o ba ṣe nkan ti ko dara pupọ a ko le ṣe ju pe ki a mọ ọ loju lọ.

Àgbà-ìyá ranṣẹ ki nwọn pe Iyunade fun on. Igbati onitọhun de, dipo ti iba si fi mã ba a sọrọ ki o gba a ni iyanju ki o fi ohun ti o ṣe ti ko dara han a, ko ṣe bẽ̩, o yi wọle o fa paṣan yọ o fẹ na Iyunade, ọwọ ti o gbe soke bayi, ki o to ba a de ilẹ Iyunade ti bẹrẹ o ti ko o l'ẹsẹ, o di gbẹ̀, ipakọ Àgbà-ìyà ní lẹ. Àgbà-ìyá tun ṣe kàtìkàtì dide o tun ni ki on lu Ìyunade, lẹ̀keji Iyunade tun ko o lẹsẹ, ogedengbe l'o ba ori lọ silẹ, ki a má sa fa a gun lọ titi ẽmẹta ni Iyunade gbe Agbà-ìyà lulẹ, igbati o si di ẹlẹ̀kẹta yi, ṣe lo ki ẹsẹ rẹ̀ mọlẹ ti o nwọ Àgbà-ìyà lọ, gbogbo awọn obinrin ile ba da àbàrá bo Iyunade, awọn ẹgbọn rẹ̀ nã kó paṣan ya a, ki nwọn to gba ẹsẹ Agba-iya lọwọ Iyunade. Nwọn lu diẹ si ara Iyunade nwọn le e o sare ṣìàṣìà o sọkun oju rẹ̀ fẹrẹ fọ nitori bi igbati enia da ori aṣa Yoruba

kọ òdò ni pe ki ọmọde gbe ọwọ soke ki o lu agbalagba. Sibẹ, bi a ba wo o dãdã, Àgbà-ìyà ko ṣe dãdã to. Njẹ ẹ tilẹ mọ nkan ti o tun buru ju, ẹhin ti nwọn gba Àgbà-ìyà silẹ tan o tun nfọnnu. O nba Iyunade leri o ni, "Mo gbe e mo fẹ fi ori rẹ na okuta ni, kini ṣe ti ẹ mu wa? Ẹ ba jẹki nnà a dãdã." Nà a dãdã? Ṣe ni nwọn mà gba ẹsẹ rẹ kuro lọwọ Iyunade.

Igbati o di owurọ ọjọ keji ni Ademẹtọ pe Iyunade ti o ba a wi dãdã ti o wi fun u ki o lọ bẹ ẹgbọn awọn, Àgbà-ìyà, Iyunade bẹ Agba-iya dãdã fun afojudi ti o ṣe, ṣugbọn nigbati Ademẹtọ wi fun u ki o bẹ Àdììtú, ó kọ jalẹ patapata o ni, "Ẹgbọn mi, nko le bẹ Àdììtú rara, ẹ jọwọ ẹ jẹki nlo ọla ti Olodumare fun mi gẹgẹ bi obinrin. Lọna kini, Àdììtú ki iṣe ọkọ mi, ki itilẹ ṣe ọkọ afẹsọna rara, ki a wipe a fẹ ara wa nijọmiran ni mo le bẹ ẹ ṣugbọn eyini pãpã ko le bọ si i, lọna keji, enia melo ni ilẹ yi l'o le mọ pe on ni mo nkọrin bu lana, ẹni melo l'o le mọ pe on ni mo npe ni Ògòngò Ọrùn. Ko si ẹniti o le gbọ pe mo wipe ọrun rẹ gun jù ti nwọn ko ni wipe emi pãpã nṣiwere ni, nitori emi nã mọ pe ọrun rẹ ko gun mo ra ẽbu nã mo fi mọ ọ lara ni. Mo ṣe ë lati fi rẹ igberaga Àdììtú silẹ, ṣe o ye yin, ẹgbọn mi. Lẹhin nã pãpã, õtọ ni a kọrin ti o dabi ẹni pe a nbu u lana, ṣugbọn owo ti mo ná fun awọn ti o ba egúngún jo nkọ? Kekere ni? Njẹ awọn ti o ri mi ti mo jo kiri ode lana nitori ọjọ ibi rẹ ko ni mã sọ nkankan si mi. A! Ki nbẹ Àdììtú-Olodumare tabi nla!—Emi kọ afi bi o ba jẹ baba mi kọ l'o bi mi."

Àdììtú ni tirẹ kẹ, ko dakẹ bẽ ṣe l'o nba orukọ Iyunade jẹ kiri a ni bi o tilẹ fi ara rẹ bẹ on, on ko jẹ fẹ ẹ mọ, bẽni irọ l'o npa ifẹ ti ràdọ bo o, ifẹ ti ti ilẹkun mọ ọkan Àdììtú-Olodumare, ó mu kọkọrọ lọ, ati mu ọkan rẹ kuro lara Iyunade ko ṣẽ ṣe.

Igbati Ademẹtọ bi Iyunade idi rẹ ti o fi wipe ọran ki awọn mejeji fẹ ara awọn nijọmiran ko le ṣẽ ṣe, esi ti Iyunade fun u ni pe Àdììtú ni igberaga jù ni ti on. Bi ẹni pe o mọ nkan ti Àdììtú nsọ kiri nipa on ni, bẽni igberaga yi nã ni ko jẹki ó le nà tan fun awọn ọrẹ rẹ pe ifẹ ọmọ nã wà ni ọkan on.

Ṣugbọn nkankan ṣa ni, lati igba yi, bi Àdììtú ba de ile Ademẹtọ, o ba a o, ko ba a o, Iyunade mã ntọju rẹ dãdã, a mã ṣe bi ẹni pe on tubọ fẹran rẹ si i, bi ko ba Ademẹtọ ni ile a ni ki o





joko ki on yara wa a lọ, a gbe aga fun u. O nhuwa bi-ẹni pe o mọ pe on ti ṣẹ Àdììtú. Àdììtú ko kọ ẹnu fifẹ si i o si tilẹ wa dabi ẹni pe on pãpã ti kó ọkan kuro ni ti Àdììtú papapata.

O wa ṣe, Iyunade mura o lọ si ẹhin odi kan ni ọjọ kan, ọkọ oju omi l'o si ni lati wọ de ọhun.

Ademẹtọ mọ pe Àdììtú tun nba ọkọ nã lọ si ilu keji ti o ṣaju ti Iyunade diẹ ṣugbọn o tilẹ gbagbe patapata lati sọ fun Iyunade pe Àdììtú nba ọkọ nã lọ. ko si sọ fun Àdììtú pe Iyunade nlọ. Ọkọ ti ṣi to wakati meji ni Àdììtú fẹ lọ si ibi Ile Igbọnsẹ afi pẹkírẹkí ti o pade Iyunade, awọn mejeji kàn kìtí, nwọn rẹrin si ara wọn.

Iyunade bẹrẹsi ronu idi rẹ ti on fi dede ri Àdììtú bẽni onitọhun nã nronu àdédérí yi ti o si fi jẹ pe ọrẹ on ko sọ fun on tẹlẹ. Àdììtú gbagbe, Ademẹtọ gbagbe ni, ṣugbọn Iyunade ro pe on ati ẹgbọn on ni nwọn pa idi apo nã pọ. Ibiti nwọn ti nro eyi ni oju ọrun ti bẹrẹsi dudu, ti awọn ọlọkọ nsa soke sa sodo ti nwọn nwi fun olukuluku enia ki nwọn mã pe ohun ti nwọn nsin, awọn onigbagbọ inu ọkọ ti bẹrẹsi kunlẹ nwọn ngbadura awọn onimale nã mu ilẹkẹ lọwọ nwọn nke pe Alah, oniṣango nlu ṣẹ́rẹ̀ ṣango, ọlọya nlu ilu ọya, onifa nda ifa, awọn abọriṣa gbogbo si bẹrẹsi lu ilu oriṣa wọn. Iji fẹ ja.

Ṣugbọn kini yi ko gbọ, iji bẹrẹ, a gbe ọkọ lọ si oke, a nà a mọlẹ, a tẹ ọkọ, omi a rọ wọle, ki a má sa ba a lọ bi ilẹ bi ẹni, ọkọ da oju de. Ẹrọ l'o nwa ọkọ nã tẹlẹ o, ṣugbọn ki iji pãpã to bẹrẹ ni ẹrọ ọkọ ti dede dakẹ ti ko ṣiṣẹ mọ. Àdììtú dì mọ ẹ̀fọ́ ọkọ̀ kan ti ko rì o na ẹsẹ sinu omi, omi ngbe on ati ẹ̀fọ́ ọkọ̀ yi kiri. Ẹfọ ọkọ̀ nã gun Àdììtú ko le ri aye ri odi keji rẹ Igbati o pẹ ti omi ti ngbe ẹ̀fọ́ ọkọ̀ yi ka, o gbe e de erekuṣu kan, Àdììtú ba di igi kan mu leti omi o fi ẹsẹ ti ilẹ o bọ si ori erekuṣu. Wíwò ti o wo iwaju, kil'o mã ri? Iyunade. Ọn ti di mọ ẹ̀fọ́ ọkọ̀ kannã lapa ọhun. Ninu gbogbo ero ti o wà ninu ọkọ, awọn mejeji yi nikan ni nwọn là ninu ijamba nã. Erekuṣu ti nwọn wà, nwọn ko mọ ọ ri, nwọn ko tilẹ ri ẹnikẹni.

Awọn mejeji rọjú wọ̀ si ori ilẹ ni, nitori o rẹ wọn pupọ nwọn ti gbe wakati mẹta dãdã loju omi.

Ṣugbọn Àdììtú ki irin ki ó má gbáradì dãdã, ki o to kuro

ni ile o da apo rọ́bà kan, o ko onjẹ si i dãdã, ẹkọ, ẹba, ọka gbogbo, nwọn wa pẹlu ọbẹ̀ ẹran ti nwọn ti din ni epo ti nwọn fi ata si dãdã, titi ọkọ si fi rì yi, apa rẹ̀ ni apo onjẹ rẹ̀ wa, o gbe onjẹ nã de erekẹṣu yi koko.

Igbati Àdììtú simi yo tan, o lọ si ọdọ Iyunade. O sọrọ si i, nwọn bẹrẹsi fi ọwọ lu ọwọ nwọn ndupẹ lọwọ Ọlọrun Ọba. Igbati Àdììtú mu akaṣu ẹkọ ti o tu u ti o mu ẹran adiẹ ti o fi le e lori ẹnikẹni ko wi fun Iyunade ti ebi ti pa ti inu rẹ̀ ti di pẹlẹbẹ ki o to wọ́ gẹrẹ si eti awo ti o njẹun.

Ọkunrin ko ni ṣai ṣe ọkunrin, igbati nwọn jẹun yi tan, eyini ní nkan bi dẽde agogo mẹrin ọsan, Àdììtú rin eti erekuṣu lọ o nfẹ wo bọya on le ri apẹrẹ kan ti yio fi ibiti awọn wa han on.

Ibiti o ti nlọ bayi, afi igbati o wọ nkankan bi ọkọ ti o nbọ loju omi, igbati nkan nã mã de, o ďi ara ẹ̀fọ́ ọkọ wọn ti ọpọlọpọ okùn ti lọ́ mọ jánganjàngan gbogbo. Nigbati ẹfọ ọkọ yi de ibiti Àdììtú wa o fi igi fa a mọra. Igbati o fa ọkan ninu awọn okun ti ó lọ́ mọ́ ẹ̀fọ́ ọkọ̀ l'o ri i pe nkankan tun so mọ ọ ni isalẹ, o ba fa a, igbati o sa mã fa a de oke, o ri apoti nla kan, ṣiṣí ti ó ṣí apoti yi wo, o kun fun iṣãsun, àwo tanganran, o tilẹ ni àbẹ́là ati iṣana ninu pẹlu, ọkan ninu wọn ko fi ara ba omi, Àdììtú ba tun nwa awọn okùn wọnyi kiri. Igbati o tun mã fa ọkan soke nkọ, apoti nã ni, eleyi kun fun aṣọ obinrin, ẹkẹta ti o mã fa jade jẹ apoti gàrí, bẽni iyọ ati ata tun wa nibẹ. Awọn apoti wọnyi ni nwọn ti dì lọna ti omi ko le de inu wọn rara, ṣe ni inu wọn gbogbo gbẹ patapata.

Iyunade ko si nibiti Àdììtú ti ri awọn nkan wọnyi, o ba yara sare o lọ mu ihin ayọ nã ba a.

Ṣe ni ọkan awọn mejeji si wa balẹ dẹ́dẹ́, nitori nwọn mọ pe awọn ní igbẹkẹle kan, nwọn ro ninu ara wọn bayi pe igbati onjẹ ti awọn ní ba fi mã tan o yẹ ki awọn gburo ẹniti yio kó awọn yọ.

Lalẹ ọjọ yi, Àdììtú mu pupọ ninu aṣọ ti nwọn ri ninu apoti fun Iyunade ki ó tẹ́ sun. O fun u ni eyiti o mã fi bora ati eyiti o mã ṣù ni òṣùká fun irọri, on nã tẹ ọkan silẹ, o sun le e, o da ọkan bora o ṣu ọkan ni oṣuka fun irọri pẹlu.





Nwọn balẹ ài balẹ ni nwọn sunlọ, agogo mẹjọ si lu ni owurọ ọjọ keji ki nwọn to ji, nwọn sunlọ bamubamu ni, nitori ãrẹ ti o mu wọn. Lọjọ keji ni Àdììtú ti bẹrẹsi yi inu igbo erekuṣu nã ka bọya a jẹ ri oju ẹsẹ ẹranko ki o bẹrẹsi dẹ okùn mu wọn nitori igbati ọbẹ̀ ti nwọn ni yio ba fi tan. Lõtọ nã, o ri oju ẹsẹ ẹranko kítikìti. Ni ọjọ kẹta ti nwọn de erekuṣu yi ni Àdììtú fi okùn mu òdù ọ̀yà kan. Ni ọjọ kẹrin, ko pa ẹran, ni ọjọ karun ko pa, ṣugbọn ni ọjọ kẹfa, o pa õrẹ nla kan. Ṣe ni nwọn bẹrẹsi jẹ ẹran wọ̀mù ti Iyunade nã nse ọbẹ ti o nwọle ti o nwọ ode bi iyawo ọlọ́dẹ.

Nwọn gbe oṣu kan-abọ bamubamu ti nwọn ko gburo ẹnikan. Ni akoko yi, bi ọkọ ni Àdììtú nṣe fun Iyunade, bi aya nã ni Iyunade si nṣe afi ti pe nwọn ko nsun ti ara wọn.

Ni owurọ ọjọ kan, nibiti Iyunade ti ntu inu gbogbo apoti wo o ri ohun ikọwe kitikiti. Afi bi ẹni pe nwọn ti jọ sọ fun ara wọn ni, olukuluku mu ohun ikọwe, o nkọwe lọ. Nibo ni nwọn ha nkọwe si? Nwọn ko kọwe si ibikan tabi si ẹnikan ju ara wọn lọ. Iyunade nkọwe si Àdììtú, Àdììtú nkọ si Iyunade ẽkanṣoṣo ni nwọn si jọ fi iwe fun ara wọn. Ẹ jẹki a wo ohun ti nwọn kọ. Ki a kọ yẹ ti Iyunade wo.

Erekuṣu Àimọ̀,
Ọjọ kọkandilọgbọn oṣu
kẹjọ, Ẹdẹgbẹwa Ọdun O le
Mejidilọgọta lẹhin Iku Oluwa wa.

Onitemi Ọwọn,

Kil'o ro pe mba kọ ni iwe si ọ? Kil'o ro pe o tọ si ọ? Kil'o yẹ ki nṣe si ọ, Olufẹ mi, lõtọ o ko kọwe pe ki nfẹ ọ loni, lõtọ, o ko sọ ọ ni ọrọ ẹnu, lõtọ ko si nkan aṣiri ti a ṣe fun ara wa pamọ, ṣugbọn mo fẹ sọ nkan ti obinrin ki isaba sọ, mo fẹ kọ nkan ti obinrin ki isaba kọ, nko fẹ lati duro de ọrọ ìdùnnú ti obinrin mã nduro de lati ọdọ ọkunrin, mo fẹ wi fun ọ pe mo mã fẹ ọ. Wo o, Àdììtú, bi ejo ba bu enia ṣan bi a kọ ba tete dá ẹjẹ ibẹ duro, oró a lọ si apa, oró a lọ si ẹsẹ, oró a lọ si gbogbo ara, asẹhinwa asẹhinbọ oró a wọ inu ọkan lọ, bi oró ejo ti nrin ni ifẹ rẹ nrin kiri lara mi, iyatọ ti o wa ko si ju pe bi oró ejo ti wa fun ibanujẹ bẽni ifẹ rẹ ntọ̀ mi lara fun ìmúnúdùn, ó bẹrẹ lati ẽkan ẹsẹ o ba a de irun ori mi, o kuro

ni irun ori o ba a de ẹ̀dọ̀, o ba a de iwe, o ba a de ẹ̀dọ̀fóró, o wà ni ọgangan õkan aiya mi loni yi gãn, mo fẹ lati fẹ ọ.

Ṣugbọn, olufẹ mi, Olodumare ju ọmọ enia lọ. Mo ti mọ lọkan mi tẹlẹ ri pe ó le ṣẽ ṣe lọjọ miran ki á mã gbe bi tọkọtaya, ṣugbọn, ki ẹnikan wipe bayi ni ọran nã yio ṣe bọ si i wẹ́rẹ́, emi o wipe irọ ni oluwarẹ̀ pa. Ki a sọ pàtó, ọjọ pẹ ti mo ti fẹran rẹ, Àdìitú, ọjọ ti mo ti fi oju kàn ọ ni o ti wù mi, ṣugbọn ọrùn ti o fi wu mi ju ni mo fi nbu ọ. Ede awa obinrin wà ni orişirişi, ó jinlẹ pupọ, ede miran, ẹnikan l'o ye, ẹniti ede nã mbẹ ninu rẹ̀ si ni, ede wa miran pẹlu ye ẹni meji, omiran si ye ju ẹni meji lọ. Gbogbo iwọnyi, isalẹ inu mi l'o wa, mo de e mọ apoti ikùn mi, Mo fi kọkọrọ rẹ̀ pamọ bẹ́rẹ́bẹ́rẹ́. Loni yi, o wa to akoko ati sọ. Mo tun sọ tọkantọkan, Àdìitú mi ọwọn, mo fẹ ki o jẹ onitemi. Ki o di ọkọ mi, ki o jẹ bãle mi, ki o di ẹniti o ni mi torítorí, ẹniti o ni mi tọrùntọrùn, ẹniti o ni mi ti-gbogbo-ara ti-gbogbo-ara, ẹniti ng o fi pẹlu Olodumare gẹgẹ bi alagbẹkẹle mi.

Mà á mã reti ẹsi iwe yi were were.

Emi ni tirẹ loni, lọla, lọtunla ati titi lailai.

Iyunade.

Iwe ti Iyunade kọ ni eyi, ṣugbọn ti Àdìitú nã fi ara we e, bayi ni iwe tirẹ̀ ṣe lọ,

Erekuṣu Àimọ̀,

Ọjọ Kọkandinlọgbọn oṣu

Kẹjọ, Ẹ̀dẹgbewa Ọdun O le

Mejidilọgọta lẹhin iku

Oluwa wa

Ọ̀kín mi ọwọn:

"Ẹiyẹ bi ọ̀kín ṣọwọn ninu gbogbo ẹiyẹ, ọ̀kín lẹwa ju gbogbo wọn lọ, ọ̀kín ni dudu lara bi agbe, ó ni pupa lara bi aluko, o tun ni funfun lara bi ologoṣẹ. Adaba ko le duro nibiti ọ̀kín wà, oriri ko le sọrọ nibiti ọ̀kín duro si, Alapandẹdẹ ati Odidẹrẹ, Ìbáákà ati ẹ̀gà, Lekeleke ati Aparo, Òdèré kókò ati Aṣẹrẹ, gbogbo wọnyi a pa lọlọ nibiti Ọ̀kín ba gbe duro. On ju wọn lọ. Ó ni ọla ju wọn lọ ọdọ ọlọ́lá ati ile ọlọ́lá ni a si iti iri i. Iyunade, iwọ ni ọ̀kín mi. Ko si iru rẹ ninu awọn obinrin, o ju gbogbo wọn lọ.

Ọrọ ti mo mã sọ ko ni ṣai ti ye ọ. Mo sọ ọ lẹ̃kan ri, njẹ nko ti sọ ọ? Njẹ nko ti wi bẹ̃? Mo ti wi i. Mo ranti dãdã pe mo sọ ninu iwe mi si ọ ni ọjọ kan pe Olodumare ju gbogbo enia lọ, pe o le kàn a nipa





fun ọ pe ki o fẹ mi, o si le kàn a nipa fun mi pe ki nfẹ ọ. Njẹ o kàn a nisisiyi tabi kò kan á o? O kàn á tabi ko kàn á? Ninu ogunlọgọ awọn enia wọnni, ko si ẹniti o là ninu wọn bi ko ṣe iwọ bi ko ṣe emi. Ọna wo ni Ọlọrun le fi sọ ọ fun wa ti o ju eyi lọ?

Nitorina, Iyunade, mo fẹ lati fẹ ọ, mo si fẹ ki o gbà bẹ̃ fun mi. Bi mo ba fẹ ọ tan, gbígbé ni ng o mã gbe ọ gẹ̀gẹ̀ ni gbogbo ọjọ aiye mi, owo ko ni pọn-ọ loju, iyà kan ko ni tọ le ọ, ng o si mã ṣe ãjo rẹ titi ng o fi fi aiye silẹ ni. Nkan ti o ba fẹ ni mo mã mã fẹ, nkan ti o ba kọ̀ ni mo mã kọ, bẹ̃ni ẹnikẹni ko ni gba aye rẹ lọwọ rẹ, bi nkan ba de si ọ o de si mi, bi nkan ba kàn ọ, ó kàn mi, bẹni ohunkohun laiye yi ko ni láálàṣi rẹ.

Iyunade, njẹ o tilẹ mọ bi o ti jẹ? Njẹ o mọ bi o ti jẹ lọwọ mi? O dabi itanna olõrundidun kan ti ẹnikan gbin sinu ọgba rẹ̀ ti ko jẹki gbogbo ẹniti nkọja lẹhin ọgbà lọ mọ, nitori õrun nã dun jọjọ. Gbogbo ẹniti nkọja lọ nduro, nwọn ko le lọ, aṣẹhinwa aṣẹhinbọ, nwọn bẹrẹ si wa irugbin itanna nã, nwọn wa a titi nwọn fi ri i, bẹ̃ni gbogbo wọn bẹrẹsi gbin itanna yi kiri, nwọn gbin i si ila õrun, nwọn gbin i si iwọ rẹ̀, nwọn gbin i si Gusu, nwọn gbin i si Ariwa, bẹ̃ni nwọn gbin itanna yi kãkiri aiye jakejado—bayi gãn l'o ri iwọ Iyunade, bayi ni ọlá rẹ, iwa rẹ ati ẹwà rẹ, ẹ̀rín rẹ ati ìrìn ẹsẹ rẹ nfa gbogbo enia mọra. Ati ọjọ ti mo ti kọ ri ọ ni ifẹ rẹ ti ràdọ̀ bò mi bi adiẹ ti iràdọ̀ bo ẹyin rẹ̀, ifẹ rẹ bò mi mọlẹ bamubamu, nko si ni le gbadun aiye yi rara lái si rẹ. Nitorinã, dandan ni ki o wa bi o ti mã ṣe mi si, bi nko tilẹ dara ni ẹwà, jọwọ jẹki ndara loju rẹ, bi iwa mi ko tilẹ sunwọn jọwọ jẹki o sunwọn loju rẹ, mo si fẹ ki o mọ pe bi o ba le fẹ mi ile mi di tirẹ, ọna mi di tirẹ, ohunkohun ti iṣe temi si di tirẹ lailai.

Ireti mi pọ pupọ lori iwe yi, jọwọ má si ṣe jẹki ireti mi di ẹyin adiẹ ti o di òbu, maṣe jẹki ireti mi já si asan, mo bẹ ọ tapátapá, mo bẹ ọ tẹsẹ̀tẹsẹ̀, mo bẹ o tojútojú, mo bẹ ọ timútimú, mo fi ile mi bẹ ọ, mo fi ọna mi bẹ ọ, mo si fi ilẹ ọrẹ pẹlu ẹgbọn rẹ bẹ ọ ni Erekuṣu yi loni, ki o jẹki ifa rẹ fọ rere si mi.

Mo nreti esi ni were were.

Emi ni tirẹ lọla, lọtunla, nírèní ati titi lailai.

Àdìitú.

Ẹ wo iwe ti awọn mejeji kọ si ara wọn. Iyunade fi ọwọ mu tirẹ̀ lọ o nà a si Àdìitú, bi Àdìitú ti ngba a, o na tirẹ̀ si i. Ọrọ ko tun ni esi mọ, nwọn ti fesi fun ra wọn. Igbati nwọn ka a tan, ekini duro o nwo ekeji, ekeji duro o nwo ekini,

ẽkanṣọṣọ ni nwọn sa si ara wọn ti nwọn dì mọ ara wọn pàpà jájá.

Nkan ti Olodumare ba mã ṣe aṣetan ni iṣe e. Lọjọ yi gãn okùn ti Àdìitú dẹ ko pa ẹranko, bi on ati Iyunade ti yọ̀ mọ̀ ara wọn tan ni ọkan rẹ̀ lọ si ibiti o dẹ okùn yi si, igbati o mã wo o, ẹiyẹ ni okùn mu, ẹtù si ni, bẽni ẹtu a mã dun lẹran. Were ni Iyunade se ọbẹ̀ ti awọn mejeji jẹ ti nwọn yo dãdã.

Ṣugbọn ijangbọn ki ifi ibi nkan rere silẹ. Mo rò pe ẹmi Eṣu l'o mu eleyi wa. Eṣu ko fẹran ọmọ enia, ojõjumọ ni mã jowu wọn nitori agbara nla ti Ẹlẹda fi fun awọn ọmọ araiye.

Ṣe ni nwọn jẹun tan ti Iyunade rin diẹ si isalẹ bayi ní Erekuṣu nã, "He!" Igbe ni Àdìitú gbọ. O ke si i ko dahun, o tun ke, ko gbọ nkankan, o ba lọ si apa ibi isalẹ ti Iyunade lọ, O de ibẹ o wa gbogbo ibẹ, ko ri ẹniti o jọ Iyunade, o ba bẹrẹsi wa a kiri, o wa a, wa a, wa a, o wa a titi, ko ri i. O wa bẹrẹsi wá gbogbo erekuṣu yi kiri, o pinnu ati wa gbogbo kọ̀rọ̀ ti o wa nibẹ ibã ṣe oke ibã ṣe pẹtẹlẹ, ibã ṣe ilẹ lile ibã ṣe inu àbàtà, o nwa Iyunade kiri, õgun bo o lara, omi ti wẹ̀ ẹ́ fun õgun ti o nlà. Igbati o pẹ ṣa afi igbati o dede ri ọna kan ti o ba inu igbo kan bayi lọ. O ri i pe nwọn kan igi pẹlẹbẹ kan mọ igi nla ti o wà ni ẹba ọna ibẹ nwọn si ya ọfà kan ti o kọ ori si oju ọna yi. Nkan ti o wà ni ara igi pẹlẹbẹ nã ni yi:

"Kiyesi ọna yi dada, MAṢE GBA IBẸ̀, ILU AWỌN TI NJẸ ENIA NI IBẸ BA LỌ, ẸRAN ENIA NI NWỌN FI NJẸ IYÁN, ON NI NWỌN FI NJẸ ỌKÀ, ON NI NWỌN FI NJẸ ẸBÀ, ON NI NWỌN SI FI NJẸ ẸKỌ. ẸRAN APA ỌMỌ ENIA, ẸRAN ẸSẸ ATI ẸRAN TI O WÀ NÍ IBI ÌBÀDÍ NI NWỌN FI NSE EWẼDU, ON NI TI ỌBẸ ILA, ON NI NWỌN SI FI NSE ẸFỌ. ẸDỌ̀-KI ENIA, ẸDỌ̀-FÓRÓ ENIA, ṢÀKÌ ENIA, ATI IWE PẸLU, NI NWỌN NBÙ LÉ ORI IRẸSI WỌN. BẸ̃NI AGBARI ENIA NI NWỌN FI NMU ẸMU, NI NWỌN FI NMU ỌTÍ ON NI NWỌN SI FI NMU OMI, NWỌN A FI EGUNGUN ENIA ṢE APOTI NWỌN A JOKO LE E. ẸNITI O BA JÀJÀ SANRA GBÉ, ẸNITI O BA PUPA KAN ÌJÀNGBỌN, BI O SI SANRA BI O





KO SANRA ILU IKỌSILẸ NI, ẸNIKAN KO LỌ SIBẸ KI Ó BỌ RI — ṢỌRA!"

Igbati Àdìitú ka akọle yi, ibẹ l'o kọ ori si, ọkan rẹ̀ sọ fun u pe awọn ni nwọn mu Iyunade lọ. Ọna ibẹ ko dabi ẹni pe ẹnikẹni ntọju rẹ̀ rara, kiki igbo ni. Igbati Àdìitú rin to bi wakati kan l'o bẹrẹsi ri ile koriko ti nwọn kọ ṣúkuṣùku kiri, ṣugbọn ko ri ẹnikẹni, o sa nlọ o nlọ o nlọ ṣa. Igbati o pẹ o ngbọ ohun ọpọlọpọ enia ni ibikan, ọkan rẹ̀ si sọ fun u pe bọya nwọn pejọ nwọn nfẹ pa Iyunade ni, o ba rọra yi si inu igbo o nba ẹ̀gbẹ́ igbo lọ ki ẹnikẹni má ba ri i. Lõtọ, igbati o ṣe, o ri wọn. Nwọn pejọ, igbati o si wo iwaju bayi, Iyunade l'o ri ti nwọn de e mọ igi ti nwọn da epo si i lara, o ku iṣẹju marun pere ti nwọn nilati ṣa ina si i lara ki nwọn sun u jẹ. Ṣugbọn nwọn nbọ mọlẹ̀ wọn, nwọn njo yi Iyunade ka gẹgẹ bi aṣa wọn.

Kini ki Àdìitú ṣe? O ranti pe on mu iṣana lọwọ ati pe bi ina ba sọ ni apakan dandan ni pe ki awọn ajẹnia yi lọ wo ibẹ, o ba pada o ṣa ina si ile ni apa isalẹ bayi, ina sọ, ki eyini to de oke o tun tì sa wa apa oke o ṣa ina si ile ibẹ, were ni ina sọ niwa lẹhin, ṣe ni gbogbo wọn tuka ti nwọn sa lọ si ibi ile wọn. Ki nwọn to pada Àdìitú ti mu ọ̀bẹ o ti ja gbogbo okun ti o de Iyunade mọlẹ o ti fa Iyunade l'apa, iré ya. Iré ni nwọn sa titi nwọn fi de ibiti nwọn pa ibudo si.

Ṣugbọn ara awọn mejeji ko balẹ mọ. Bawo ni awọn ajẹnia wọnyi ṣe ri wọn? Eleyi wa lọkan Àdìitú pupọ, ọ ba tun mura o lọ si ibiti o ti ri akọle oju ọna ilu wọn lẽkan bọya on tun le jẹ ri nkan miran ti o le ran awọn lọwọ. Lõtọ, o ri, igbati o wo apa isalẹ akọle ti ó kọ́ ri, ó rí iwe kekere miran ti nwọn kọ bayi,

BI O BA FẸ PẸ́ DIẸ NI EREKUṢU YI, RIN ẸSẸ MẸFA SI APA OSI KI O WA WO APA ỌTUN RẸ O Ó RI IHO KAN FOFORO, DI I, IHO YI JÁ SI ILU AWỌN AJẸNIA, IBẸ NI NWỌN SI LE GBA RI Ọ.

Lõtọ igbati Àdìitú rin ẹsẹ mẹfa si apa osi rẹ̀ ti o wa wo apa ọtun o ri iho yi, awọn Ajẹnia ni nwọn gbẹ ẹ lati ilu wọn ja si Erekuṣu, ni apa ọdọ tiwọn, nwọn fi digi kan si i ti o jẹ pe o le ri nkan ti o wa ni wakati mẹfa si wọn dãdã. Idi rẹ̀ ti



‘ Ki nwọn to pada, Àdìitú ti mu ọ̀bẹ, o ti ja gbogbo okùn ti o de Iyunade mọlẹ ’





nwọn ko fi tete mọ pe awọn meji yi wa ni erekuṣu nã tẹlẹ ni pe nwọn ko rin de ọ̀gangan iho yi, igbati nwọn ba si tilẹ nkọja ibẹ, nwọn ko bọ si akoko ti awọn ajẹnia nwo digi ti ọdọ wọn. Àdìitú ba di iho yi dãdã, Iyunade na ran a lọwọ lati di i.

Igbati o ṣe ṣa ti ọkan wọn balẹ, nwọn wa nmura ati sun nitori ilẹ ṣu. Àdìitú mu aṣọ meji o fẹ lati tẹ ibusun awọn mejeji pọ̀. Ṣugbọn Iyunade ko gba bẽ, o kọ̀ fun u o ni, “Dìitú, Dìitú temi, gbọ mi sẹ, jẹk'a rọju k'a de 'le ki a to mã sun ni busun kan pọ, ki awọn enia mi mọ mi l'aya rẹ, ki nwọn mọ-ọ, l'ọkọ mi. Ẹni a bi 're ko gbọdọ huwa ẹ̀tẹ́, gbajumọ ko gbọdọ huwa aṣa. Lagbara Ọlọrun Ọba a mã d'ele dandan.”

Àdìitú nã ko jiyan, ṣugbọn ibiti o duro si ni Iyunade ti dide ti o gba aṣọ lọwọ rẹ̀, o ni, “Iṣẹ mi l'o nṣe mo ṣebi emi ni mo ti ntẹ aṣọ wa tẹlẹ ri tabi kini toni ti jẹ?” O mu aṣọ o tẹ aṣọ si ọna meji, nwọn ba sunlọ.

Odidi Oṣu meji bamubamu ni nwọn fi wa ni erekuṣu yi ti nwọn ko gburo enia ti enia ko gburo wọn. Nwọn jẹ gari titi, gbaguda fẹrẹ hu lori wọn. Lọjọ ti gari wọn tan gãn ni nwọn ri igbala. Ṣe ni nwọn dede ri ọkọ awọn apẹja kan ti o yọ ni apa isalẹ ti o ṣe bi ẹni mbọ, igbati o tun ṣe, ó ṣẹ́ ori pada, nwọn ke, ke, awọn apẹja ko gbọ ni Àdìitú ba bẹ́ lu omi ti o wẹ̀ lọ si ọdọ wọn, igbati o ṣe o de ọdọ wọn o ba rohin bi ọjọ ti pẹ ti awọn ti de erekuṣu yi ti to.” Awọn apẹja wọnyi ba wọn dupẹ lọwọ Ọlọrun Ọba pe awọn ajẹnia ko ti pa wọn jẹ. Nwọn ni, Ikúpàdé l'a npe erekuṣu yi, eti ilu awọn ajẹnia l'o wà, ẹniti nwọn ba si ti ri, oluwarẹ̀ gbé.”

Awọn apẹja wọnyi ni nwọn pada lọ gbe Iyunade ti nwọn ko ohun ini wọn ti ó kù si erekuṣu Ikúpàdé ti nwọn si mu wọn lọ si ebute ti nwọn ti le ri ọkọ tãra wọ̀ lọ si Ajedubulẹ.

Ni ọjọ ti awọn mejeji yọ si Ajedubulẹ, ilu dàrú nitori gbogbo enia l'o ṣebi nwọn ti ku. Inu aṣọ ọ̀fọ̀ ni nwọn ba Ademẹtọ ati ọ̀bí Iyunade mejeji, bakanna si ni fun Àdìitú ati awọn ti o jẹ enia rẹ̀.

Igbati Iyunade bẹrẹsi rohin fun ẹgbọn rẹ̀ Ademẹtọ, diẹ l'o kù ki nkan ti o nwi ṣe ài ye e nitori ko pe Àdìitú ni Àdìitú

mọ, Onitemi l'o npe e. Ẹgbọn mi, àní awọn ajẹnia mu mi ki Onitemi to de, Onitemi l'o mu ọ̀bẹ t'o fi ja okùn ti nwọn fi dè mi, wo mi, ẹgbọn mi, ṣe ni ki ẹ dupẹ lọwọ Onitemi dãdã. Onitemi ọ̀ọ̀, ẹ ba mi pe Onitemi ki ó tilẹ wa rohin fun ẹgbọn mi. Iwọ da? Onitemi, wa rohin fun ẹgbọn mi kẹ, ati bẹ̃ bẹ̃ lọ.

Ko pẹ pupọ ti nwọn de ṣa ki Àdììtú to ran enia wa ki nwọn lọ tọrọ Iyunade fun on. Ki a má sa fa a gun bi ilẹ bi ẹni nwọn fi igbeyawo si oṣu mẹta lẹhin ti nwọn de.

Lojojumọ po ni nwọn nri ara wọn lãrin oṣu mẹta yi nitori ko si ọjọ ti Àdììtú ko ni de ile Iyunade.

Ọrọ kekeṙe kan bayi ṣa l'o fẹrẹ da ija silẹ lãrin wọn. Bayi ni :—Ọkunrin kan wa ti o jẹ ẹniti Àdììtú gbẹkẹle pupọ ni Ajedubulẹ orukọ rẹ̀ ni Eṣu-lẹhin-ibeji. On ni o wà ni ikawọ pupọ ninu iṣẹ Àdììtú gbogbo on tilẹ ni enia le wipe o tẹle Ademẹtọ ninu awọn ọrẹ Àdììtú ti a ba tò wọn bi Àdììtú ti ṣe fẹran wọn lẹsẹsẹ. Igbati Àdììtú fi wa ni erekeṣu ko jẹki iṣẹ bajẹ. Dídé ti o si ti dé l'o kó gbogbo owo ti o pa silẹ de e, fun u, ọkan ko din nibẹ. A ko le mọ iye ile ti o ti ra fun Àdììtú ni Ajedubulẹ bẹ̃ni a ko le sọ awọn mọto ti nkó enia ti ibikan de ibikan tabi ayọkẹlẹ ti o ti ba Àdììtú ra. Lõtọ abẹ Àdììtú l'o ti nṣiṣẹ, ṣugbọn a le pe e ni ọrẹ gãn. Lọjọ kan, iwe ti ó kọ si ọga rẹ̀ ni yi :

Ajédùbúlẹ̀
Ọ̀pópó Ìdàrúdàpọ̀,
Ọjọ keji Oṣu kẹsan ni ẹ̃dẹgbẹwa ọdun o le
Mejidilọgọta lẹhin iku Oluwa wa.

Ọgbẹni Àdììtú Temi Pãpã,

Mo yọ lọpọlọpọ fun dide ti Olodumare ṣe e ti ẹ de ba gbogbo wa mo si ngbadura loju mejeji pe ki Ọlọrun Ọba le jẹki ẹ jẹ iṣẹ ọwọ yin. Ki ẹ jẹ ẹ titi ki ẹ darugbo kàngẹ́ ki o to di pe ẹ ki aiye pe o digbõṣe. Ẹnyin nã mọ pe bi a ba wipe tani ko fẹ ki nkan yin bajẹ ni ilẹ yi, iba diẹ ni enia le tọka si ki o to tọka si mi. Ẹnyin nã ri i pe gbogbo igbati ẹ fi wa ni erekuṣu, iṣẹ yin ko duro rara were ti ẹ de ni mo si ti gbe owo ti a pa ki ẹ to de fun yin, mo ka irinwo apo silẹ gba-ndi.





Nisisiyi, ọrọ ti mo fẹ sọ yi ṣoro ṣugbọn mo nilati sọ ọ láì kọ nkan ti yio mu wa. Enia ki isaba gba ọrẹ rẹ̀ ni iyanju pe ki ó má ni obinrin, ṣugbọn obinrin ti o ba mã ṣe yin ni ijamba yio kọkọ ṣe emi ná.

Iyunade ti ẹ nfẹ yi ko tẹ mi l'ọrun rara, bawo ni ki a ti gbọ ọ pe iru iyawo yin l'o di ẹniti nsun ni ile onile ti o nsun ti ọkunrin ọlọkunrin kiri gbogbo. Ni gbogbo ọsẹ ti o kọja, ko da mi loju pe o sun orun ẹ̃meji ni ile wọn, ọdọ ẹnikan ni eti ile wa ni isalẹ yi l'o nsun, oju mi gbangba bayi ni mo si fi nri i. Ẹ̃kan ti o fura pe mo ri on, were l'o wa mi wale ti o tun pe mi lọ si ile rẹ̀. Wo mi ọga mi, iyãra l'o mu mi wọ̀ nigbati mo de ile rẹ̀ tan. Bi ko ba ṣe ẹniti o fẹran yin ni, idẹwo nla ni eleyini iba jẹ. Ṣugbọn emi kọ, emi ti mo ti jẹ ata jẹ epo, jẹ iyọ yin kọ. Bayi ṣa ni iwa ọmọ nã ri.

Ẹnyin ẹ ranti gbogbo awọn ọmọkunrin ti o ko jọ ni ijọsi nigbati o fi mu egúngún jade ti o nkọrin bu yin kiri. Eleyini pãpã tun ti ya ẹnikẹni lẹnu?

Nitorina, mo fi ori baba ati iya yin ti o ti ku.bẹ yin, ẹ mu ọwọ kuro ni ọran ọmọ nã.

Emi ni tinyin patapata laiku ibikan
Eṣu-lẹhin-ibeji.

Bayi ni iwe ti ọrẹ Àdììtú kọ si i ri, Àdììtú ki isi isaba kọ nkan si i lẹnu. O fẹran rẹ̀ gãn.

Ṣugbọn, kini kan pere l'o kù ti o ya Àdììtú lẹnu, on ni pe ọsẹ ti Eṣu-lẹhin-ibeji wipe Iyunade nsun lode yi, ojojumọ ni o nlọ si ile rẹ̀. L'ọsẹ na ṣa, ko nduro to agogo mọkanla alẹ bi iti mã duro ri, nitori o ni iṣẹ kan pataki ti o nṣe. Sibẹ a mã duro to agogo mẹjọ tabi mẹsan nigbamiran.

Lọjọ ti ọkunrin yi kọwe si Àdììtú gãn o kọ ọkan si Iyunade, bayi ni eyini lọ.

Ọ̀pópó Ìdàrúdàpọ̀,
Ọjọ keji Oṣu kẹsan, ẹ̃dẹgbẹwa
Ọdun o le mejidilọgọta lẹhin
iku Oluwa wa.

Iyunade mi tõtọ,

Ẹ wo mi, ẹ jẹki nsọ fun yin, iyi ilẹ yi ni ẹ jẹ fun gbogbo wa. Awa nfi yin ṣe fọ́rịfọ́rị kiri ni. Ẹwà ti Ọlọrun fun yin, ìwà ti Ọlọrun fun yin, ọlá ti Ọlọrun fun yin, ọlà ti Ọlọrun fun yin, ohùn orin ti Ọlọrun fun yin ati ohun gbogbo ti ẹ ni patapata, Olodumare ko ni gba a lọwọ yin.

Ẹ jẹki nsọ fun yin, ẹ ti ṣá ọkan mi l'ọgbẹ pupọ sẹhin, ọgbẹ nã ko si ti di nla, ko si si õgun ti nko fi si i tan, sibẹ ọgbẹ yi ko jina. Ẹ ti wu mi ọjọ ti mo mã ri yin ti mo mã nle jẹun bi mo ba de ile. Ni ṣoki mo fẹ lati fẹ yin pupọ, ẹ wu mi pupọ ju, ẹ wu mi tayọ. Ni ti owo, ṣe aya ko si si ohunkohun ti ẹ nfẹ ti nko le ṣe fun yin. ó wà, ni ti agbara ó wà, ni ti enia mímọ̀ o wà fun mi dãdã.

Ṣugbọn sibẹ nko ba ti le sọ ọrọ yi jade fun yin bi ko ṣe nkan ti o nbọ ti nko fẹ ki o de ọdọ yin. Àdììtú ti o ntẹle yin gulegule ko ni ifẹ yin rara. Obinrin ti o nkó kiri ti pọ ju, ṣe ẹ mọ pe a jọ nṣiṣẹ ni. Ojõjumọ ni npãrọ obinrin, eyiti ó sùn tì loni kọ l'o mã sùn tì lọla. Eyiti o tilẹ wa buru ju lọ patapata ni gbese. Iṣẹ ti emi rẹ jọ nṣe, Àdììtú ti ba a jẹ patapata tobẽ̩ ti o jẹ pe ọsẹ ti mbọ ni Oyinbo nbọ wa ti ile rẹ ti ó ní ni ilẹ yi gbogbo.

Bi Oyinbo ko tilẹ ti ile o, ọjọ on pãpã ko pẹ l'ode aiye yi mọ, mã wo ohun ti yio ṣẹlẹ lalẹ ọjọ marun loni, ni agogo mẹjọ alẹ. Ọkan ninu awọn ti Àdììtú jẹ ni gbese ti wipe on nilati yinbọn pa a ni.

Igbati o ba ku nkọ, nibo ni ki tinyin gbe si, bẽ̩ni nkan ti mo gbọ dãdã ni. Ni abẹ igi ọ̀mọ̀ ti ko jina pupọ si ile yin ni nwọn yio ti yinbọn si i ibẹ ni yio si ku si.

Jọwọ ẹ maṣe gbagbe ọrọ mi yi, mo nfẹ esi ni alẹ ọla, ng o duro si abẹ igi ọsàn ti o wa leti ile yin ni nkan agogo mẹsan alẹ. Ibẹ ni ki ẹ ti ba mi.

Emi ni tinyin titi ọjọ iku,

Eṣu-lẹhin-ibeji.

Iwe bayi ni ẹnikan ṣoṣo kọ si awọn mejeji yi. Igbati Iyunade ka tirẹ tan o fi sinu àpamọ́wọ́ rẹ o si ti pinnu pe bi Àdììtú ba ti de lalẹ ni on o fi le e lọwọ.

Lõtọ Àdììtú wa lalẹ ṣugbọn ṣe l'o ro oju korokoro ti o di ẹnu dudu. Iyunade ki i, ko dahun, o bẽre ọrọ lọwọ rẹ, imu l'o fi sọrọ. Igbati o ṣe ṣa, o pe e si iyara kan, o de ọhun o kunlẹ fun u o ni on fẹ lati bẹ ẹ ni kini kan, ati pe nkan nã ni pe ki Àdììtú lọ ṣọra pupọ lara Eṣu-lẹhin-ibeji.

Kini Àdììtú gbọ bẹ ṣe, ṣe l'ó bẹrẹsi ọrọ buburu sọ si Iyunade o ni, "Ki emi lọ ṣọra? Ki emi lọ ṣọra lara Eṣu-lẹhin-ibeji? Iwọ gãn, iwọ, iwọ Iyunade gãn ni mo nilati ṣọra lara rẹ. Iwọ, iwọ rádaràda kan lásán làsàn yi."

Iyunade ko gbin mọ, o rọra dide ni ilẹ tũ, o bọ si iyãra,





o gbe apamọwọ rẹ, o fa iwe Eṣu-lẹhin-ibeji yọ, o fi le Àdììtú lọwọ. O fi Àdììtú si õdẹ, o bọ si agbala, o nwa onjẹ.

Àdììtú ka iwe, o mọ ọwọ Eṣu-lẹhin-ibeji dãdã. O tun iwe ka, o tun tun u ka, o ka a titi, itiju papọ mọ iyanu ko si ẹniti o fi ẹhin enia jalẹ bẽ̩ ri. Àdììtú dide, o de agbala, o dọbalẹ tãn niwaju Iyunade, obinrin rẹ afẹsọna. Iyunade ati Adììtú rọra dakẹ jẹjẹ, igbati o di alẹ ọjọ ti o ni on nbọ wa gba esi, Àdììtú rọra yọ kẹlẹkẹlẹ lọ wo abẹ igi ọsan ti Eṣu-lẹhin-ibeji darukọ, kedere l'o ri Eṣu-lẹhin-ibeji ti o duro ti o nreti Iyunade.

Àdììtú ki iṣe ẹniti nṣe nkan jàùjàù o mọ pe o ku ọjọ mẹrin si i ti Eṣu-lẹhin-ibeji wipe ẹnikan yio duro de on ti yio pa on, o ti fura eyi pe Eṣu-lẹhin-ibeji gãn ni ẹniti yio yinbọn nã. Ki o to di ọjọ yi, Àdììtú ti ba aburo Eṣu-lẹhin-ibeji di ọ̀rọ̀ kan pọ, o ni on fẹ lati ṣe nkankan ti yio pa Eṣu-lẹhin-ibeji lẹrin pupọ, on fẹ ki aburo rẹ gãn yọ si i ni ibikan bayi ti Eṣu-lẹhin-ibeji yio ṣe bi on, Àdììtú ni, o ba aburo Eṣu-lẹhin-ibeji yi di i dãdã pe ki ó má jẹki ẹgbọn on gbọ. O wa mu aṣọ ti ara rẹ o fi wọ aburo Eṣu-lẹhin-ibeji, igbati ilẹ ba ṣu tan ni nkan yi yio to ṣẹ gẹgẹ bi iwe Eṣu-lẹhin-ibeji. Igbati ilẹ wa ṣu wayi o, aburo Eṣu-lẹhin-ibeji mbọ ninu aṣọ Àdììtú-Olodumare, ni ọkánkán ibiti Àdììtú mã nba lọ si ile Iyunade ni alãlẹ. Riri ti Eṣu-lẹhin-ibeji ti o ti gbe ibọn lọwọ ri i, o ṣebi Àdììtú ni, kẹ̀—mù : — : — ù ibọn dahun, aburo Eṣu-lẹhin-ibeji ku. Eṣu-lẹhin-ibeji ko mọ ẹniti on yinbọn si nitori yíyìn ti o yin ibọn ni o ti salọ. Ero rẹ ni pe on ti pa Àdììtú-Olodumare.

Afi Àdììtú afi Iyunade nikan ní gbogbo Ajedubulẹ ni nwọn mọ ẹniti o ku ati ẹniti o pa a. Igbati Eṣu-lẹhin-ibeji tilẹ si salọ ko sa ba ile lọ. Ilu kan ti o wa lagbegbe Ajedubulẹ l'o kọ ori si, nitori ki ọran iku Àdììtú má ba kan on rara.

Ó jí de ni owurọ ọjọ keji ni nkan bi agogo mẹjọ-abọ. Ẹ wa wo bi ara rẹ ti mã gbọ̀n to ti o jẹ pe bibọ ti o nbọ Àdììtú ati Iyunade l'o pade ti nwọn fi ọwọ kọ ara wọn lọwọ ti nwọn nlọ, awọn l'o si kọ ki i ti aburo rẹ ti o ku.

Àdììtú ko fi iwe Eṣu-lẹhin-ibeji silẹ rara ko iti ifẹ ba a ṣe ẹjọ, o fẹ ki awọn ọlọpa-inu ṣe iwadi wọn bi agbara wọn ti

to ñá, ki işe pe ko ni sọ gbẹhin, şugbọn ko iti ifẹ sọ, o si pa a laşẹ gãn fun Iyunade pe ki ó má sọ fun ẹnikẹni.

O to ọsẹ mẹrin ki Àdììtú to pinnu lati sọ. Arẹmọ ọba Ajedubulẹ jẹ ọrẹ Àdììtú, ãfin ọba si ni Ajedubulẹ ti fẹ ko ọran nã lọ.

Şugbọn ni ọjọ gãn ti Àdììtú lọ si ãfin ti o da ọrọ nã silẹ, bi o ti fi ẹnu ba a ti o darukọ Eşu-lẹhin-ibeji ni Arẹmọ ti o lọ ki ju ọwọ si i pe ki ó pa ẹnu rẹ mọ awọn nfẹ mu u ni ãfin ni akoko nã, o ti bá ọkan ninu awọn iyawo arẹmọ şe eto pe on nbọ wa si ọdọ rẹ, o mọ pe ọba ko gbọdọ ri ọkunrin k'ọkunrin pẹlu obinrin ãfin. Onitọhun ti wi fun ọkọ rẹ nwọn ti to enia ka ẹhin ile gbogbo. Ko pẹ, Eşu-lẹhin wọle obinrin, şugbọn o wọ ọ ài wọ ọ ni arẹmọ de ti o kan ilẹkun obinrin. Eşu-lẹhin wà ninu ile, o ni "Tani?" Onitọhun nã dahun, "Bãle ni." Were ni Eşu-lẹhin mu ikoko nla gìdànyìn kan ti o şi i bo ori. Arẹmọ wọ iyãra, iyawo şẹju si i, şişi ti nwọn şi ikoko ti Eşu lẹhin wo oju arẹmọ, gbùrà ti o ta, o bi arẹmọ lulẹ, arẹmọ yí bítábítá, awọn ọmọ ile ọba gbá nwọn fi le e, o sa gun ori ile, nwọn gun ori ilẹ ti i, o sa gun ori igi nwọn nbẹ igi ni isalẹ o tun ja lori igi, o di odò o bẹ lu omi, nwọn bẹ́ ti i. Asẹhinwa asẹhinbọ, nwọn mu Eşu-lẹhin-ibeji, nwọn bẹrẹsi gba a loju gba a ni mu, titi nwọn fi mu u ti nwọn tì i mọle.

Şugbọn Ọba Ajedubulẹ le pupọ, ipa oró l'o pa Eşu-lẹhin-ibeji. Şugbọn ko pa a nitori iyãra obinrin ọmọ rẹ ti nwọn ti ba a, o pa a ni ipa oró nitori Iyunade ni, pe Eşu-lẹhin-ibeji dede ba ọmọbinrin ọlọmọbinrin jẹ to bi ò ti ba a jẹ ninu iwe ti o kọ si Àdììtú. Bi onitọhun ko ri eyiti o tun kọ si ọmọ nã pãpã nkọ? Bi iwe ti ó kọ si ọmọ ba sọnu nkọ tí Àdììtú ko ri i? Ìbá ba aiye ẹni meji jẹ kalẹ, iba tun ba ti iran ti nbọ jẹ, nitori iba ba aiye Àdììtú jẹ, iba si tun ba ti Iyunade jẹ, bẹni iba ba aiye ọmọ inu wọn jẹ. Ọba ni, "Enia bayi, iku oró l'o yẹ ki o ku, awọn enia nilati fi han pe awọn kọ̀ ọ laiye, Olodumare si mã kọ̀ ọ l'ọrun, ẹ mu u, ẹ yọ oju rẹ kan, ki ẹ yọ ọ silẹ ki nmã wo o niwaju mi nisisiyi." Bayi ni ọba nã sọ, were were ni nwọn yọ oju Eşu-lẹhin-ibeji kan. Lẹhin eyi, ọba nã tun paşẹ "Ẹ yọ ekeji, mo nfẹ ẹ ni werewere." Nwọn tun yọ oju keji. Lẹhin nã ó ni, "Ẹ ge apa rẹ kan ki





ẹ fẹrẹ ge e ja, ẹ ge apa keji bẹ̃, ẹ ge ẹsẹ rẹ kan ki ẹ fẹrẹ ge e ja, ẹ tun ge ikeji bẹ̃, ẹ maşe ge wọn ja patapata." "Nwọn tun şe eleyi, Eşu-lẹhin-ibeji wa ninu irora nla."

Nigbẹhin, ọba ni ki nwọn gbe ọkọ on nla ti nwọn fi nkó kòkó jade, ki nwọn wa mu Eşu-lẹhin-ibeji ki nwọn di i mọ táyà (tyre) ọkọ lọna ti o jẹ pe dipo ki taya fi ara balẹ ara Eşu-lẹhin-ibeji ni yio fi balẹ. Ẹhin nã ọba wipe ki nwọn wa ọkọ nã lọ ni nkan bi mẹli mẹwa, ki nwọn wa mu abọ fun on. O paşẹ bayi tan, o dide gbogbo enia si ke "Kabiyesi, Alaşẹ, ekeji orişa."

Igbati nwọn fi ma de, apa ti ja sọnu sinu igbo, ẹsẹ ti sọnu sinu ọdan, ori Eşu-lẹhin-ibeji ti ja sinu omi.

Igbati o şe ti Àdììtú-Olodumare gbeyawo, o ri i pe Iyunade ko mọ ọkunrin kan ri ninu aiye ki o to di pe o fẹ on.

Pupọ ninu awọn ọmọ enia ni ode oni, l'o yẹ ki nwọn ku iku ti Eşu-lẹhin-ibeji ku, awọn wọnyi ko si fun ilọsiwaju fun ẹnikẹni, nwọn wà fun ibajẹ, awọn ni igi ẹgun, igi oşuşu lãrin ọmọ enia, pupọ ninu awọn ọkunrin ni nwọn ti sọ obinrin anfani nu nitori nwọn ti bọ si ọwọ awọn igi ẹgun wọnyi. Ẹ wo Eşu-lẹhin-ibeji, ọrẹ gãn ni fun Àdììtú Olodumare, sibẹ ẹ wo ibajẹ ti o şe, on gãn ni o gba Àdììtú ni iyanju ki o fi Iyunade silẹ, àşé on gãn nfẹ lati fẹ Iyunade, ẹnikẹni ti o ba ni ero pe inu iwe nikan ni a ti le ka itan yi, ati pe ko si iru rẹ ninu aiye mọ, omugọ patapata ni oluwarẹ, omugọ oluwarẹ ni o ta omugọ gbogbo yọ, Eşu-lẹhin-ibeji pọ lọ sũ, awọn ni nwọn npin pupọ ni ìyà ninu awọn afẹsọna ọkunrin ati ti obinrin, ko si aniani pe awọn mã jiya tiwọn ná, nwọn nilati jẹ pupọ ninu rẹ lode aiye, nwọn yio ma jẹ iyoku lode ọrun.

# ẸHIN IGBEYAWO ÀDÌÌTÚ-OLÓDUMARÈ

Igbeyawo Àdìitú-Olodumare on Iyunade dun tobẹ̃ ti dídun rẹ̀ ṣọro lati ṣe apejuwe, nitori Ọlọrun bukun ọkunrin nã pupọ. O ni owó nã ti ko ṣẽ fi ẹnu sọ. On pãpã si lawọ́ ko l'ahun kan rara. O nawo nã gãn ni. Ọba nla gbogbo l'o pe jọ pẹlu ade ori wọn, ijoye pataki pataki tẹle ara wọn gẹ̀rẹ̀rẹ̀ ti awọn ti ilẹkẹ l'ọrun, ati olowo ti o ni mọto nla gbọlọku, ati talaka ti o nfi ẹsẹ rẹ̀ rin, ko si ẹniti ko jẹ yo dãdã. Nwọn jẹ jẹ jẹ, nwọn mu, mu, mu, nwọn jo jo jo, nwọn yọ̀ yọ̀ yọ̀, gbogbo ilu nmì titi, awọn ọmọ enia nwọle awọn ọmọ enia njade. Gẹgẹ bi aṣa ilu Ajedubulẹ ọna meji pataki ni inawo iru igbeyawo bẹ̃ nilati pin si. Ọna kini ni ki oniyawo nawo igbeyawo bi a ti ka silẹ yi, ọna keji ni pe ki o dá gbogbo enia l'ara ya ninu ile ẸNÚDÙNJUYỌ̀.

Ile Ẹnúdùnjuyọ̀ wa fun itan sisọ, bi ẹnikẹni ba si ti mã ṣe inawo yi, o nilati lọ ba Mọgaji Ile Ẹnúdùnjuyọ̀ ki o polowo kakiri ilu, ki o fi iwe lẹ ita kakiri ṣugbọn o nilati fun Mọgaji ile yi ni owo pupọ. Nwọn fẹrẹ má ni iṣẹ meji ti nwọn nṣe ninu Ile Ẹnúdùnjuyọ̀ ju pe ki nwọn mã sọrọ ki nwọn mã gba owo lọ. Ẹnu wọn dun pupọ, ko si si itan ti ko si lẹnu wọn.

Igbati Àdìitú ti san owo Mọgaji fun Mọgaji tan ni nwọn ti fi iwe lẹ ode bayi pe

KI EKU GBỌ KI O WI FUN ẸIYẸ, KI ỌKUNRIN GBỌ KI O WI FUN OBINRIN, KI ỌMỌDE GBỌ KI O WI FUN AGBALAGBA, PE ÀDÌÌTÚ-OLODUMARE TI GBE IYUNADE NI IYAWO, O TI NAWO FUN GBOGBO ENIA O SI TI ṢE ETO FUN MỌGAJI ILE ẸNÚDÙNJUYỌ̀ O. ITAN SISỌ FUN AJỌYỌ, YIO BẸRẸ NI AGOGO MẸSAN OWURỌ ỌJỌ KỌKANLA OṢU KẸSAN NI ẸDẸGBẸWA ỌDUN O LE MEJIDILỌGỌTA LẸHIN IKU OLUWA WA. A PE GBOGBO YIN LÁÌ KU ẸNIKAN—MỌGAJI ILE ẸNÚDÙNJUYỌ̀.

Akiyesi yi ni nwọn fi si ita kãkiri. Igbati o si di ọjọ nã,





gbogbo enia pe nwọn bo ile Ẹnudùnjuyọ̀ ṣíkanṣíkan, eyiti o joko le ori aga joko le ori aga, eyiti o duro, duro, bẹ̃ni ọkẹ aimoye ọmọ enia ni nwọn joko le ori ẹni lọ bẹ̃rẹ.

Igbati nwọn joko bayi tan ni Mọgaji ile Ẹnúdùnjuyọ̀ jade. Àdìitú ati iyawo rẹ̀ joko le ori aga gà-ǹgà kan, nwọn gún gẹ́gẹ́ ninu aṣọ.

Mọgaji ile nã lakoko yi dagba pupọ, gbogbo irun ori rẹ̀ l'o funfun lẹ́lẹ́ fun ewu, iba diẹ ni irun nã pãpã si tilẹ kù nitori gbogbo ori ti bù pá tán ãrin ori dabi isalẹ iṣãsun ọbẹ̀, o ndan kõro.

Nigbati o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni:

"Gbogbo ẹnyin ọmọ Ajedubulẹ, mo ki yin, gbogbo alejo Ajedubulẹ, mo ki yin, mo ki onile, mo ki alejo, mo ki oṣo, mo ki ajẹ, mo ki babalawo, mo ki adahunṣe, mo ki olowo, mo ki talaka, mo ki ẹniti o ri jẹ, mo ki eyiti ko ri jẹ, gbogbo ẹnyin igbagbọ, mo ki yin, gbogbo ẹnyin imale, mo ki yin, gbogbo ẹnyin abọriṣa mo ki gbogbo yin porogodo."

"Ẹ wo 'hin" (ó nàka si Àdìitú ati Iyunade) "Àdìitú-Olodumare gbe Iyunade ni 'yawo, nwọn ba 'ra mu tabi nwọn ko ba 'ra mu?" Gbogbo enia dahun, nwọn ni, "Nwọn ba 'ra mu." O bi wọn lẹ̃keji, nwọn dahun, o tun bi wọn lẹ̃kẹta nwọn tun dahun bakanna.

Lẹhin eyi o wa nba ọrọ rẹ̀ lọ o ni:

"Ki nto mã ba ọrọ mi lọ, mo fẹ lati ran yin leti, gẹgẹ bi aṣa wa pe lọjọ meje loni ni Àdìitú ati aya rẹ̀ yio wa si ihin ti nwọn o dupẹ lọwọ ara ọrun ati ara aiye, mo fẹ ki ẹ wa lọjọ nã bi ẹ ti wa loni, ki ẹ ba tọkọtaya yi ṣe ajọyọ igbesi aiye tuntun wọn."

Ninu gbogbo nkan ti o wa ni ode aiye ko si eyiti o daju ṣaka ju èrè iṣẹ lọ. Bi ẹnikan ba nṣe ibi, ó gọ̀ ni, nitori iba gbọn, on iba mọ pe ibi mbọ wa bi ibi le on lọwọ gẹ̃rẹ, bi enia ṣe õre ṣugbọn ti ẹlomiran npe e ni ibi, ki o má ṣe binu, nitori rere rẹ̀ nbọ wa fi oju han lọjọ kan gba-ngba.

Itan ti ng o sọ yi, yio tubọ la ọrọ ti mo sọ yi ye gbogbo yin dãdã. Ọba kan wà ni aiye atijọ ti orukọ rẹ̀ njẹ Òkonko-lójú-abẹ. Ní ki a wipe ọba lowo, ki a wipe ọba lokiki, ki a wipe

ọba lọ́lá, ki a wipe ọba lagbara, ki a si wipe ọba bimọ, Alaiye-luwa Okonko ko ni àkàwé. O bimọ titi awọn ọmọ rẹ ko mọ ara wọn mọ, nwọn nfẹ ara wọn, o ni ile titi o ra gbogbo ile ti mbẹ ni odidi ilu kan patapata, ẽdẹgbẹfa ilu l'o nsin on nikan lasingba lọdọ̃dun, ọba wà lara Okonko. Bẹ̃ni bi owo ti wa, ti igberiko ti pọ to nã ni ọlá wà fun u, awọn obinrin rẹ̀ bi nwọn ti pọ to nì, ọkunrin k'ọkunrin ko gbọdọ pade wọn loju ọna, ẹniti o ba pade obinrin Okonko, pipa loju kan werewere ni.

Ko si bi obinrin ti le pọ to ki ọkọ má ni ãyo kan. Ọba Okonko ni ãyo, ọkan ninu awọn iyawo rẹ tuntun ti o ṣẹṣẹ fẹ wọle si ni orukọ rẹ̀ njẹ Ẹsan-mbọ. O fẹran obinrin nã pupọ ko si le fi ifẹ rẹ̀ pamọ loju ẹnikẹni. Eleyi ko le dun mọ awọn iyoku ninu rara ati pãpã olori gbogbo wọn ti o jẹ iyãle pataki.

O wa ṣe, ọba lọ si idalẹ kan, igbati iyale rẹ̀ àgbà patapata si wa nkan ti o mã ṣe ti ko ri, o lọ wa õgun kan, ki ikuku ṣe pe õgun yi le pa enia ni, ṣugbọn bi o ba le kan ẹnikẹni lẹnu ki oluwarẹ sunlọ werewere ni, ki o si to ji, yio pẹ gãn.

Bayi l'o si ṣe ti o fi ri Ẹsan-mbọ ãyo ọba mu, ṣe on ni olori gbogbo awọn aya ọba, gbogbo wọn l'o si mã nbọwọ olori fun u, on ni gbogbo wọn mã npe ni iya, o ba Ẹsan-mbọ ati awọn iyawo miran nwọn joko nwọn nṣire ni, l'o ba ke si Ẹsan-mbọ, ti o ni, "Ẹsan temi o, Ẹsan-mbọ, mo fẹ ri ọ, fi awọn alakọri wọnyi silẹ ki a wa ṣire tiwa lọ." Ẹsan-mbọ ba tẹle e, nwọn rin la:i oju ile de oju ile, lati akodi de akodi, lati iloro de iloro, igbati o ṣe nwọn de ile iya yi. Nwọn de ibẹ àì de ibẹ l'o bẽre ti o ni, "Kil'o mã jẹ, Ẹsan?" Onitọhun nã fesi o ni, "Mo yo, iya mi." O ni, "Ni o kò ni tọ ọbẹ̀ wò rara?" Onitọhun nã tun fesi o ni, "Ẹ má ṣe iyọnu iya mi." Obinrin yi kò mà tilẹ bẽre mọ o, ó yi wọle ni o bu ọbẹ o gbe e fun Ẹsan-mbọ, o ni, "Tọ eleyi la, kò kuku pọ, ko le yo ni, mo si ni ẹran ni ile dãdã."

Ko ni ṣiṣe ko lái ṣe Ẹsan tọ ọbẹ la, ṣugbọn ọbẹ fẹrẹ má iti ide inu tan ti orun fi mu Ẹsan lọ.

Werewere iya yi ti pe gbogbo awọn iranṣẹ inu ãfin ti o gbẹkẹle dãdã ti o si ti fun ni abẹtẹlẹ silẹ, o ni ki nwọn fi aṣọ ati ẹní di Ẹsan-nbọ ki nwọn gbe e sinu apoti nla kan ti o ti





kàn silẹ de e ti o gba onitọhun dada, ati pe bi ilẹ ba ti jàjà ṣu, ki nwọn gbe e lọ si ẹhin odi ilu nibiti nwọn ṣe ogunlọgọ iboji silẹ si. Awọn iboji wọnyi wà fun awọn iranṣẹ ọba bi ile ni nwọn si ṣe gbogbo wọn, nwọn a gbẹ iho nla, nwọn a fi simẹnti ṣe inu rẹ̀, nwọn a wa gbe ilẹkun si i lori, nwọn a de e mọlẹ. Enia si le ṣi ilẹkun yi nigbakigba ki o wọ inu iboji bi o ba fẹ. Iboji wọnyi pọ tobẹ̃ ti o jẹ pe ibiti nwọn gba to ilu kan dãdã, nitori afi bi a ba npẹgan, ọba nla ni ọba Okonko bi o ti ni iyawo rẹbẹtẹ, ni o ni iranṣẹ rẹbẹtẹ.

Ṣugbọn iranṣẹ ọba ni nwọn gbọdọ sin si ẹhin ilu, ãfin ni nwọn nsin gbogbo ayaba si, ṣugbọn iru iboji ti o ni ilẹkun yi ni nwọn nsin ayaba si, tobẹ̃ ti o jẹ pe ẹnikẹni le wọ inu iboji ni igbakigba ti o ba fẹ.

Were obinrin yi ti wi fun awọn gbẹnagbẹna ki nwọn ba on gbẹ igi ki o dabi enia gãn ki enia nã si wa jẹ ọmọbinrin. Lẹhin eyi o bẹrẹsi fọ́n owo ka, o nṣe abẹtẹlẹ ki ẹnikẹni má ba le sọ ohun ti on ṣe, o fọn owo nã ka ti ko mọ ni iba, o fọn owo ka o tun fọn dukia ka, ẹniti o fun ni aṣọ o fun u ni aṣọ, eyiti o fun ni gele o fun u ni gele, bẹ̃ni ọpọlọpọ ohun elo ni o gbe fun awọn iwẹfa ni ãfin. Bẹ̃ l'o ṣe, o fi owo bo ibajẹ mọlẹ ti o fi dukia pọ́n ibi ní gbìnrín, bẹ̃ni Olodumare dakẹ́ jẹ́jẹ́, o mọ ohun ti on mã ṣe.

Awọn ti o ti fi owo fun ṣe iboji fun igi ti gbẹnagbẹna gbẹ, nwọn di igi bi ẹni di oku, nwọn gbe e si iboji de ọba.

Ṣugbọn kini o ṣẹlẹ si Ẹsan-mbọ ti nwọ́n dé pa sinu posi lái jẹ pe o ku? Bayi ñi, ọkunrin onișowo kan wa si ilu yi lati ta ọja orukọ rẹ̀ a mã jẹ Alabapade. O jẹ enia kan ti o ri jẹ dãdã o si ko ọja pupọ wa. Igbati o di alẹ o rin gbẹ́rẹ́, gbẹ̀rẹ̀, gbẹ́rẹ́, o ṣire ba ode lọ. Ẹsẹ rẹ̀ sa dede yà si ibiti nwọn ṣe iboji rẹpẹtẹ lọ si yi ni, o ba nrin ibẹ kiri, ibiti o ti nronu ọja ti o gbe wa ko mọ igbati ilẹ ṣu ti oṣupa yọ.

Igbati o ṣe, o dede ri awọn ẹnikan ti nwọn to bi mẹrin ti nwọn gbe nkan ti o jọ apoti gbõrọ kan de, nwọn gbe nkan nã bọ sinu iho kan, nwọn ṣe bẹ̃ tan, nwọn lọ. Bi nwọn ti lọ tan ni ọkunrin yi ba ibiti awọn ọkunrin bi mẹrin wọnni gbe nkan si lọ. O de ọhun lõtọ ṣugbọn o ri i pe ṣe ni nwọn kan apoti

gbọ̃rọ ti nwọn gbe wá pa, o ba mura o di ibiti o wọ̀ si. O de ọhun o mu nkan ti yio fi yọ iṣo, o tun pada de o bẹrẹ iṣẹ o nyọ isọ wọnni. Kil'o mã ri ninu apoti? O ri obinrin ti o lẹwa tobẹ̃ ti o ṣoro lati ṣe apejuwe ẹwa rẹ̀, o nrọju mí, nitori diẹ bayi l'o kù ki ó kú patapata.

O ba bẹrẹsi tọju obinrin yi, o nfẹ òyì si i, o ṣe bẹ̃ titi, oju rẹ̀ walẹ diẹ, o ba gbera o ki ire mọlẹ o tun di ibi ẹru rẹ̀, o de ọhun o mu ọbẹ̀, ti o ti pese, o bu u, o mu ẹkọ tutu, o bu omi, o gbera o di ibiti ọmọ yi wa, o de ọhun o fun u ni onjẹ, o jẹ, o fi omi fun u, o mu, ọkan obinrin yi wa balẹ. Isisiyi wa ni Alabapade wadi ile ti o ngbe ati ibiti o fẹ ki on mu on lọ.

Esi ti Ẹsan-mbọ fun u ko ju eyi, o ni, "Iwọ ni olugbala mi, ibikibi ti o ba ngbe ni ilẹ yi ni ki o mã mu mi lọ."

Bayi ni Alapade mu obinrin o ba lọ si ibiti o de si. Ṣugbọn o dara pupọ pe Ile Ero ti o de si wà ni ikangun ilu ati pãpã pe iyawo ọba yi ki ijade si gbangba tẹlẹ nitorina ko tilẹ si ẹniti o mọ ọ rara.

Iyãra kan ni ọkunrin yi gbà ṣugbọn ibusun meji l'o wa nibẹ, on sun si ọkan, ayaba yi nã sun ni ọkan mọju. Ṣugbọn bi gbogbo rẹ̀ ti ri ko ye ayaba yi pãpã ju bẹ̃ lọ. O mọ pe inu afin ni on wa tẹlẹ o mọ pe inu iboji ni Alabapade ti ri on, ṣugbọn bi o ti ṣe de ibẹ ko ye e, ko si tun ye Alabapade pẹlu, ẹniti Alabapade papa jẹ ko ye Ẹsan-mbọ ṣugbọn o mọ pe ẹniti o ri jẹ dãdã ni, nitori ile ero ti o de si dara to ãfin dãdã, ibusun ti awọn mejeji si sun si ko re ẹhin bi a ba fi we eyiti Ẹsan-mbọ nsun ni ãfin.

Ilẹ ọjọ keji mọ, nwọn jẹun. Igbati nwọn jẹun tan ni Alabapade pe Ẹsan-mbọ ti o bẹrẹsi sọ itan ti ara rẹ̀ fun u, bi on ti jẹ oniṣowo ti Ọlọrun bukun on dãdã ti o si jẹ pe igba kini ti on mã wa si ilu nã ni on ri Ẹsan-mbọ yi. O to gbogbo nkan ti o mọ nipa ara rẹ patapata, ireti rẹ̀ ni pe igbati on ba to ti on, ayaba yi nã yio fi ẹnu le ti ara rẹ̀. Ṣugbọn, irọ ni, ko ṣe bẹ̃ rara. Nkan ti o sa sọ gbẹhin ni pe on ko ni ti isọ itan ara on fun Alabapade, ṣugbọn pe ki o ṣì jẹki awọn jọ mã gbe pọ ná.

Bayi ni nwọn nṣe, nwọn jọ njẹ nwọn jọ nmu ṣugbọn ọ̀tọ̀ ni ibusun ti olukuluku nsun ni alãlẹ. Bi Alabapade ba ti jade lọ ko





npẹ pada wale nitori ki oju má ba kun alejo rẹ̀ yi. Ọjọ kan bayi ti o ṣe bi ẹni pẹ diẹ ọrọ ãnu ni Ẹsan-mbọ sọ jade lẹnu o ni, "Kini ṣe ti o pẹ tobẹ̃, ọrẹ mi? Ko daju pe o tilẹ mọ̀ bi o ti jẹ si mi. Wo mi, olugbala l'o jẹ, alafọkantẹ ni ọ fun mi. Iwọ ni omi tutu bi ojo didi ti o nṣan lati inu apata. Ọkunrin kan ri i, nitori ti o si ti rin ni ọjọ mẹta gbako ninu ọ̀dàn láì ri omi mu, õrun ti pa a lãrọ, o ti pa a lọsan, o ti pa a lalẹ, ọna ọfun rẹ̀ ti gbẹ, bẹ̃ ni ọkunrin na sare si omi yi, o bu u, o mu u, ó ba ifun rẹ̀ lọ, ó lọ sinu apoluku, ayipada de, ẹ̀dọ̀ fóró ati ẹ̀dọ̀ ki, ọkàn ati iwe, iṣan ara ati orike, gbogbo awọn wọnyi ti nwọn ti gbona di tutu, gbogbo ara tù ú sẹ̀ẹ̀ sẹẹ, bayi l'o jẹ si mi, iwọ Alabapade, ti Olodumare gbe pade mi."

Bayi ni ọrọ ti obinrin nã sọ, ṣugbọn ẹ o ri i pe ko si nkan ti Alabapade le ri fa yọ ninu ọrọ rẹ̀. Ko si nkan ti o le ri fa yọ ju pe o gba on si ẹni pataki fun ara rẹ̀. Kò jẹki ẹnikẹni mọ ohun ti on jẹ, yala ẹrú ni on, yala ọmọ ni, yala ọmọ ọba ni on, yala ọmọ enia kan lasan ni, ko si ohun ti ẹnikẹni le sọ.

Fun igba diẹ, Alabapade pãpã ko janpata mọ, nwọn jọ nba ire wọn lọ. Ṣugbọn bi o ti wu ti obinrin fi iwa pamọ to bi o ba ni ifẹ ọkunrin kan lọkan igbati o ba ṣe, onitọhun a mọ pe o fẹ on. Bakanna ni fun ọkunrin. Bi ọkunrin ba nfẹran obinrin, ati mọ̀ obinrin ko pẹ jọjọ. Awọn mejeji wọnyi bẹrẹsi mọ̀ pe awọn nfẹran ara.

Ṣugbọn sũru ọkunrin ki ito, iba jẹ pe sũru ọkunrin a mã to ni, obinrin ni iba kọ mã sọ pe ki ọkunrin fẹ on. O dede di oru ọjọ kan ni, Alabapade kuro ni busun tirẹ̀, ó lọ si ti Ẹsan-mbọ, o de ọhun, o ji i, ó ni ki o sunmọ ẹ̀gbẹ́ ogiri, on fẹ sun ti i. Ẹsan-mbọ ba ṣana si atupa o bọ ọkan ninu awọn ẹwu ọrun rẹ̀, o wa fi nkankan han Alabapade, o fi ẹwu ti o kangun ara han a ki o ka nkan ti nwọn ti kọ si ẹgbẹ rẹ̀.

Ohun ti nwọn ti hun mọ ẹgbẹ ẹwu nã ni eyi: "EMI KO LE BA ẸLOMIRAN PIN Ọ NI ODE AIYE, EMI L'O NI Ọ TITI IKU, ALAIYELUWA, OKONKO."

Igbati Alabapade ri awọn ọrọ wọnyi, ṣe ni ara rẹ̀ rọ ilẹ wọ̀ọ̀, o ni, "Tabi ayaba ni ọ?" Onitọhun nã fesi o ni, "Ãyo ni mo jẹ pẹlu, Ẹniti mo ba ní kí Alaiye lé lọ, lile lọ ni, ẹniti mo bá si ni ki o pa, pipa ni pẹlu, Alaiye kò kó iyan mi kere ri."

Alabapade ba tun bẽre ọ ni, "Bawo l'o ha ṣe de inu apoti ninu itẹ́ oku?" On nã dahun o ni, "Eyi ko ye emi pãpã ju bẹ̀ lọ, ṣugbọn kini kan ni mo ranti, on ni pe iyãle mi àgbà patapata ní afin l'o gbe ọbẹ̀ kan fun mi ti mo lá, ṣugbọn bi mo ti ṣe de inu apoti ko ye mi dãdã." Alabapade tun bẽre o ni, "Ṣe iyãle rẹ yi fẹran rẹ?" O dahun o ni, "Ní ti oju, o fẹran mi, ṣugbọn Olodumare l'o mọ ti ọkan. Si gbọ, bi ko tilẹ fẹ mi tọkantọkan nkọ? O ṣebi o le mu u jẹ ni?—Ó tì o, gẹgẹ bi orukọ mi, Ẹsan-mbọ, ẹsan ko ni ṣai de ba a". Nigbati Alabapade wa tun bẽre ti o ni, "Ewo ni a o ha ṣe? Ṣé ki a wa ọna ki o pada si ãfin?" Ẹsan ke kàrá o ni, "Lilọ àbí nla? Bi Alaiye ba f'oju kan mi ìyà t'o mã tun fi jẹ mi yio buru ju iku lọ, ṣugbọn tirẹ kò ni aniani, pipa l'ó mã pa ọ werewere, ipa oró si ni, nitori ó ri mi lọdọ rẹ gãn, bi awa ayaba ba nbọ lọja, ọjà ntu ni. Ọkunrin ti ko ba sa, bíbẹ́ ni! On kọ, ọba ti o le ti o jù dàrọ́, ti o buru ti o ju majele lọ! Bayi ni, ṣe ni ki o jẹki a jọ mã gbe bi a ti jọ ngbe yi, awọn ti o ngbẹ agbegbe yi ko kuku mọ mi, igbati o ba si ta ọja rẹ tan, ki o jẹ ki a kuro ni ilu yi ki a wa ibomiran lọ."

Ibiti nwọn sa ba ọrọ nã de ni yi ni Alabapade fa aṣọ rẹ̀ l'eti ti o nwọ ọ lọ gẹrẹ si ibusun ti on ti sun ri.

Lati igba yi lọ, ni awọn mejeji ti mọ bi awọn ti jẹ si ara awọn nwọn jọ njẹ, nwọn jọ nmu nwọn tilẹ tubọ nfẹran ara wọn si i. Igba kan bayi ti Eṣu tilẹ fẹ bọ si ãrin wọn, ti Ẹsan-mbọ dide lãrin oru ti o lọ sun ti Alabapade, jiji ti onitọhun ji ti o ri i, ṣe l'o rọra dide ni ibusun ti o joko le ori aga.

Ṣugbọn ẹ jẹki a wa lọ wo ohun ti o ti ṣẹlẹ ni ãfin. Ọmọ-owu ti o jẹ iyãle agba awọn ayaba patapata ti o ti Ẹsan mọ apoti yi ṣe bi ó ti ku ni, nitori lẹhin eyi ti awọn iranṣẹ ọba ni afin lọ wo iboji ti nwọn ko ri apoti mọ nwọn ko sọ fun u.

Ṣugbọn o ti wa iboji ni ãfin, o mu onirũru aṣọ nla nla o fi di ere ti ó gbẹ, o gbe e si iboji yi, aṣọ aran ko ni iye, damãsi ko ṣẽ kà, o di igi yi o wu bantu, o wa mu simẹnti o rẹ́ gbogbo ayika iboji nã dãdã. O wa kun u ni ọda ni oriṣiriṣi o fi i silẹ de ọba. Gẹgẹ bi a ti kọ sọ, ṣe ni nwọn mã ngbẹ iho nla ti nwọn mã nṣe ilẹkun si i lori ti nwọn mã ngbe oku si i bi ayaba ba ku, tobẹ ti ẹnikẹni le ri oku yi nigbakigba ti o ba sa ti ṣi ilẹkun





ni. Bayi ni Ọmọ-Owú ṣe, o wa kọ akọle kan le ori iboji yi, ohun ti o kọ nã ni yi: "Nihin ni ẹni rere sùn si, Ẹsan-mbọ, ayaba ti o ju ayaba lọ, oniwatutu, oniwapẹlẹ, ọlọgbọn, oloye, iwọ, itanna olõrun didun lãrin ọmọ enia, oṣupa rẹ ṣe bayi, ó wọ okunkun l'ọsan gangan! O di gbére, mã reti mi, o di ọjọ Ajinde ki a to pade ni ode ọrun, mã mura de mi, emi nã ko ni pẹ wa ba ọ, nitori bi o ti fi mi silẹ ninu aiye yi, aiye nã ko le gbadun fun mi mọ, o digba o, ọrẹ mi, olufẹ mi, ẹni temi lailai. Lati ọwọ Ọmọ Owú, olori awọn ayaba."

Kini kan wa ni, obinrin yi, Ọmọ-Owú, ní agbara kan, o le sọkun nigbakigba, yala inu rẹ̀ bajẹ yala inu rẹ̀ dùn, igbakigba ti o ba nfẹ sọkun ki o mã ba ẹkun lọ ni, ki omi si mã da loju pẹ̀rẹ̀pẹ̀rẹ̀ ni.

Igbati ọba ti idalẹ de, ẹkún l'o lọ fi ki i, ibiti o tilẹ ti nsọkun yi ni ọba ti fura pe nkankan ti ṣe lẹhin on, igbati o si wa gbọ nkọ, ọba pãpã bú lohun rara ní oju aiye gbogbo ni, ṣe ni ohun rẹ̀ ndun bi àrá oju ọrun ti o nbu hà á hà á, loju gbogbo aiye, ohun ti ọba ko gbọdọ ṣe.

Igbati o ṣe ti ọkan ọba balẹ diẹ ti o wo iboji ti o ro pe ti iyawo on Ẹsan ni, láì mọ̀ pe ti igi ni, o dupẹ lọwọ Ọmọ-owú iyãle rẹ̀ agba pe o ṣe ẹhin iyawo rẹ̀ dara bẹ̀. Lẹhin eyi on nã wa paṣẹ ki nwọn ba on gbe akọle ti on pãpã le iboji nã. Ọrọ ti o kọ ni yi:

"A! Ẹsan-mbọ, Ẹsan-mbọ, Ẹsan-mbọ.
Obinrin wo l'ó dabĩ rẹ lode aiye?
Obinrin wo l'o le tọju ọkọ to-ọ. Ẹsan-mbọ!
Obinrin wo l'o le damọran rere to ọ Ẹsan-mbọ!
Obinrin wo l'o le wa onjẹ dara to ọ—Ẹsan-mbọ!
Obinrin wo l'o le ṣe ãjo ọkọ to ọ—Ẹsan-mbọ!
Obinrin wo l'o ṣẽ gbẹkẹle to ọ—Ẹsan-mbọ!
K'a gbẹkẹle e lori owo—Ẹsan-mbọ!
K'a gbẹkẹle e lori ọmọ—Ẹsan-mbọ!
K'ó tọju ile—Ẹsan-mbọ!
K'ó tọju ará—Ẹsan-mbọ!
K'ó tọju ara—Ẹsan-mbọ!
K'o si ẹyiti o to ọ ninu awọn obinrin
O si ṣe bayi, o lọ ki nto de? O fi aiye yi silẹ̀ fun mi?
O ti fi ilẹ bora bi aṣọ?

Ṣugbọn ẹnyin ti ẹ ti ku ti ẹ ba nwo awa ti o wa ninu aiye, ẹ maṣe gbagbe aiye o, maṣe gbagbe aiye o, maṣe gbagbe aiye o, si mã mura silẹ de mi, werewere ni mo mã wa ba ọ, nitori o ti jẹ olõtọ obinrin fun mi ninu aiye, dandan ni ki nfẹ ọ lode ọrun. Ko si ẹniti o lẹwa bĩ rẹ ninu aiye, dandan ni ki o lẹwa lode ọrun, Ẹsan-mbọ mi tõtọ, Ẹsan-mbọ mi àtàtà, Ẹsan-mbọ mi pàtó, Ẹsan-mbọ mi pataki, Ẹsan-mbọ mi, ọjọ mbọ ti a o fi oju kan ara wa.

A gbe ọwọ̀n yi kalẹ lati ọwọ ọkọ olotọ obinrin, Ẹsan-mbọ, lati ọwọ ọkọ rẹ, Alaiyeluwa Ọba Okonko."

Akọle ti ọba nã kọ si iboji obinrin yi ni a ka silẹ yi. Ẹnyin nã yio ri i bi o ti jẹ si ọba.

Ṣugbọn nkan ti o wa ni ọkan ọba Okonko ni ki ẹ jẹki a wo, nitori on l'o le ṣe anfani fun ni. Ẹsan-nbọ bimọ fun ọba Okonko ipo ti ọba si fi on si yatọ si ti awọn ayaba miran, bi ó wipe ki Okonko pa ni, ki o pa a ni, bi o wipe ki Okonko fi iya jẹ enia ki Okonko fi iya jẹ ẹ ni, ṣugbọn Ẹsan ko huwa buruku si ẹnikẹni, bi o ti fẹran awọn ọmọ tirẹ̀ l'o fẹran ọmọ ọlọmọ. Eyiti o tun wa dara pupọ ju ninu iwa obinrin nã ni pe ko ni iwa buruku nì ninu, ti o wa ninu pupọ ninu awọn obinrin lati mã ba baba jẹ loju ọmọ, awọn obinrin miran a gbin wèrèpè si ọmọ wọn ni atari, nwọn a sọ ọmọ di ijangbọn kalẹ, bi ọmọ ko ba si le ni ọkan ara rẹ̀, dandan ni ki ó ṣì ṣe. Iya ọrẹ mi kan bu baba rẹ̀ titi baba nã fi ku, o tun ku tan o tun nbu u, ọrẹ mi wa la a ye e pe, o to lati fi opin si bibu baba on, nitori ati on ati iya on, baba l'o njẹki awọn ri anfani ti awọn njẹ bi o ba tun bu baba on mọ ko ni fi oju kan on mọ lailai gẹgẹ bi ọmọ. Bayi ni pupọ ninu awọn obinrin mã nṣe.

Iru iwa yi tí ko si lọwọ Ẹsan-mbọ l'o mu ki iku rẹ̀ ká ọkọ rẹ̀ lara. Lẹhin ti o gbọ ti iku rẹ̀ ọba yi pinnu lati mã sọkun iyawo rẹ̀ nã, ni ọjọ marun marun ni igbe si nta ni ãfin lati ẹnu ọba Okonko.

Bayi ni ọba yi ṣe fun odidi oṣu mẹfa ti ko si mọ̀ rara pe Ẹsan-mbọ ko ku. O wa ṣe ni ọjọ kan ọba yi rọra fi ẹhin le ilẹ lori ibusun rẹ̀, o diju, o ṣe bi ẹni pe on sun lọ. Ko sun rara o sa nfẹ mã gbọ ọrọ ni, nitori Ẹsan-mbọ ni ẹniti imã gba a n





iyanju tẹlẹ ri on l'o si mã nsọ ohun ti on ba gbọ ni ode fun u, igbati ko si ti si mọ ọba ko gbọ nkankan, eleyi l'o mu ki ọba nã mã lo iru ede yi, ki o ṣe bi ẹnipe on sun ki ó má sun rara.

Bayi l'o sa ṣe lọjọ yi ti awọn ọmọbinrin meji ti nwọn nṣiṣẹ ni ãfin bẹrẹsi sọrọ si ara wọn. Ọkan dahun o ni, "Ọrẹ mi, awọn ọkunrin mà kuku gọ o, nwọn mà gọ̀ o." Ekeji dahun o ni, "Kil'o ri ti o fi wi bẹ̃?" Onitọhun nã tun dahun o ni, "Ti eleyi ti o npe ara rẹ̀ l'ọba ko to? Ani fun odidi oṣu mẹfa, oṣu mẹfa, fun odidi oṣu mẹfa l'o fi nsọkun ère ti o npe ni iyawo on!" Ẹnikeji nã tun nba ọrọ lọ o ni, "Gbọ mi sẹ, eyini ni pe ko iti imọ pe ère ni iyãle on fi aṣọ we ti o npe ni, Ẹsan-mbọ!" Onitọhun nã fesi o ni, "Mimọ̀ tabi nla! O ko mọ pe iyãle rẹ̀ yi ti gbe nkan fun u jẹ ni? Ṣe àná ni ọjọ ọsẹ ifa? Lana yi, bi o ba gbọ bi o ti bu bi ẹdun inu igbo yio ya ọ lẹnu." Awọn mejeji ba patẹ popo, ọkan ni "Èdì ni, iyale rẹ̀ ti di i pa b'o ṣe mi ni m'a wipe mo fẹ ri oju iyawo ọ̀hún, emi a wi bẹ̃ ni temi."

Bayi ni nwọn sa bẹrẹsi ọrọ isọ ti nwọn sọ gbogbo rẹ̀ le ọba lọwọ. Eyiti nwọn wa fi pari rẹ̀ ni igbati ọkan ninu wọn bẽre ti o ni, "Nibo ni Ẹsan-mbọ tilẹ wà? Njẹ ko ku sinu apoti ti nwọn de e mọ?" Ti ekeji mã dahun ti o ni, "Kiku tabi kini? Kò mà ku rara o, ẹniti o ti l'ọkọ miran? Alabapade l'orukọ ọkọ ọ̀hún. Ṣe o mọ ile pẹtẹsi nla kan ti o wà ni ikangun ilu ti o gbe ile ti ẹ̀lúkú ti mã njade?" Onitọhun ni, "Hãn, leti ile iya alaro kan bayi?" "Ibẹ ni Ẹsan-mbọ ngbe. Nwọn tilẹ wipe o ti sanra si i, o to yọ̀kọ̀tọ̀ yọkọtọ ṣe l'ara rẹ̀ ndan gbá à."

Ọba ko mu ọrọ nã jaujau, o rọra jẹki awọn ọmọbinrin wọnyi lọ tan o pe iyãle rẹ̀ agba, o ran a ni iṣẹ kan ti o nilati mu ki o jade ni ãfin ki o si to wakati mẹta bamubamu ki o to pada. Jijade ti ó jade, ọkunrin gende meji ni ọba pe ninu awọn iranṣẹ ti nwọn wa l'ãfin, o ran ọkan ninu wọn lọ si oko lọ bẹ́ paṣan àtòrì wa, o ni ki awọn mẹfa yoku gbe oku Ẹsan-mbọ jade ni boji ki nwọn bẹrẹsi mã tu gbogbo aṣọ. Igbati nwọn tu aṣọ tan lõtọ, ère ni nwọn ba.

Ọba rọra paṣẹ ki nwọn gbe ère yi sinu iyãra on. O joko o nreti Ọmọ-owú iyãle rẹ̀. Igbati ó de ti o jiṣẹ tan, o ni, "Kabiyesi, ijoye nã tilẹ ni awọn fẹ wa ri yin l'ọjọ mẹrin loni,

ọjọ ifa, mo ni ki nwọn má wa nitori lati ọjọ ti ọfọ Ẹsan-mbọ ti ṣẹ̀ yin inu yin ko dun lọjọ ifa mọ—húù, húù, húù, (iyãle nsọkun) omi si nda pẹ̀rẹ̀ loju rẹ̀." Ọba ni ki nwọn mu u lọ, ère Ẹsan-nbọ wà ni iyara ọba.

Nigbati nwọn mu u lọ tan, yiyi ti o yi si kọrọ kan, niwaju ọba, gbangba ni ọba ngbọ ẹrin ti o nrin. Ọba ni ki nwọn ba on pe e. Bi o ti de, ti o ni, "Kabiyesi nwọn ni ẹ npe mi," ni ọba yi wọ ile ti o ni ki on nã wọle wa gbọ ọrọ kan. Iyãra ti o wọ bayi, ti o wo iwaju, ère Ẹsan-mbọ l'o ri. Ọba ba bu si ẹrin kan bayi o ni, "Mo ri i pe o ti sọkun èké tan o wa ku ki o sọkun ti ododo," o di, wáì, wáì wáì paṣan lara òkú-ùgbẹ́. Igbe ta o di "Dakun, kabiyesi, kabiyesi, ẹ dakun, ẹ jọwọ Alaiye ẹ jọwọ, mo ni k'ẹ jọwọ Alaiye, ẹ ṣãnu mi, ẹ́ ro ti ya mi." Alaiye ko gbọ, eyiti o si buru ju lọ pata ni pe bi ọba ba nna ni, a ko gbọdọ di paṣan mu. Ṣe ni ọba pa ilẹkun de ṣa ko fi kọkọrọ ti i ṣugbọn ẹru nba awọn enia lati wọle. Titi o fi nke pe "Alaiye Alaiye, ẹ fẹ pa mi ni? Ẹ jọwọ ẹ má pa mi" Ati bẹ̃ bẹ̃ lọ, ẹnikẹni ko wọle.

Igbati o ṣe, on pãpã wa ọna o ṣilẹkun o sa jade, ọba sa tẹle e, o bẹ́ lu iyãra kan ọba bẹ ti i, o fo ti oju ferese jade ọba tun bẹ jade o nle e lọ, igbati o ṣe ti o ja si ibikan ni ãfin ti nwọn da ikoko nla gbogbo de 'lẹ si, o ṣi ọkan ninu awọn ikoko wọnni o fi bo ori, ọba wọ ibẹ ti i, igbati ọba ko si ri i mọ o fura pe ikoko l'o fi bo ara rẹ̀ mọlẹ, o ba ni ki nwọn ba on mu òòlù ti awọn kafinnta fi mã ngba iṣo wọle nwọn mu u fun u, ni ọba ba bẹrẹsi fọ ikoko kiri. Igbati o na òòlù mọ ikoko ti Ọmọ-owú fi de ara rẹ̀ mọlẹ idi ikoko fọ, ori yọ si ita ganbóro. Okonko ba kó ìgbátí bo o, o di, gbà :—gbà : gbà :—gbà. Iyãle ba bẹrẹsi bu bi kiniun. Ẹ̀ gba mi o, ẹ̀ gba mi lọwọ Alaiye o, ẹ̀ gba mi o. Ẹ jọwọ ẹ gba mi, ẹ gba mi, e, e, e, ẹ gba mi." Ko tun ri ẹni gba a titi o fi ti inu ikoko jade ti o sa lọ ti o si jade patapata kuro ni gbàgede ãfin. Ọba yi danna si obinrin nã loju, ṣugbọn nigbati o sa jade tan ṣe ni ọba pãpã nmí fúgbefúgbe.

O wa ku Ẹsan-mbọ wayi o. Ọba ti gbọ pe o nba ọkunrin miran gbe. Nkan ti ọba kọ ṣe ni pe o ran awọn iranṣẹ moji ni ãfin ki nwọn lọ wadi bi o ba jẹ pe õtọ ni Ẹsan ngbe ibiti







'E gbà mi, ẹ gbà mi lọwọ Alaiye o'

nwọn nwi, bi o ba jẹ bẹ̃ ki nwọn wa wi fun on ki on ran ẹniti yio lọ gbe ori ọkunrin nã wa fun on.

Awọn iranṣẹ lọ, ṣugbọn awọn mejeji ti ọba ran ko le lo inu meji si Ẹsan-mbọ nitori o ti huwa rere si wọn sẹhin, o ti kẹ wọn o ti gẹ̀ wọn o ti yẹ wọn si.

Nkan ti o tilẹ tun nilati mã bi ọba ninu ti ko sọ jade fun ẹnikẹni ni pe Ọmọ-owu ti o jẹ iyãle ti ó lé Ẹsan-mbọ lọ yi ko ni ẹwa olõkan lara, ọba jogun rẹ̀ ni, ãfin ni ọba ba a, ẹniti o kọ gun ori oye l'o fẹ ẹ wale. Obinrin nã ko ni jògbò obinrin lara rara, kiàkia bi ọkunrin l'o ri, o si ga o wa ni ara diẹ, gbagidi bayi l'o ri, ti imu ri kọ̀ndù kọndu, ẹrẹkẹ ri kàngìrì kangiri, ẹhin ri kànnàgùn kannagun, oju yọ sode o ri kàn-ǹdò kan-ndo, eti gbõro o ri gbògà gboga, ọrun gùn o ri gbọ̀-ọ̀rọ̀ gbọọrọ, ori wa kere ori ri ṣugudu, ṣugbọn iwaju gbõro iwaju ri fẹrẹgẹjẹ, ipakọ wu ịpakọ ri kọ-ndu, ẹsẹ tobi ẹsẹ ri bakiti. Ẹniti o jẹ pe ko le sọrọ jẹ̃jẹ̃ bi obinrin a sọrọ hàmù lasan, bi o ba njẹun a jẹun bi ẹni pe aja njẹun, bi o ba nhanrun a

hanrun bi ẹni pe ojo nkù, bi o ba si rẹrin ohun rẹ̀ a gba gbogbo afin nitori ariwo—iru ẹni bayi l'o wa le iyawo ti o dara l'ẹ́wà ti o tun dara níwà lọ.

Igbati nwọn de ọhun ti nwọn ri Ẹsan-mbọ, nwọn ṣe ofofo fun u ohun ti ọba fẹ ṣe. Alabapade jade ni akoko yi, bi o si tilẹ jẹ pe Ẹsan-mbọ bẹ̀ wọn ki nwọn duro diẹ ki on ba le ri i pe Alabapade salọ nwọn ko le duro nitori ki ọba má ba fura. Bi nwọn ti jade ni on nã jade ti o wa Alabapade lọ. O ri i lãrin ọja nibiti o ti nna ọja lọwọ, o ba fa a lọwọ ki o tẹle on. Bi nwọn ti bọ si kọ̀rọ̀ diẹ o ni, "Pade mi, mura, werewere, ki iku má ba pade rẹ ṣe ni ki o mã sa lọ ọba nranṣẹ bọ wa mu ọ." Alabapade ni "Ó ti gbọ?" O ni, "Ó ti gbọ o, ẹnikan ti sọ fun u." Pade tun ni, "Iwọ nkọ?" On nã fesi o ni, "Temi ko sọro," obinrin a mã mọ nkan ti ọkunrin le ṣe, mo mọ pe ko le pa mi, yio fi iya jẹ mi ni, ṣugbọn ti o ba le fi oju kan iwọ iku oró ni yio jẹki o ku. Mura mã sa lọ. "Nibo ni ki nsa lọ?" "Sa jade lọ si ibikibi." Were ni nwọn de ile, Ẹsan nmura o di ẹrù jẹ́jẹ́rẹ́ kan fun Alabapade o fi owo kọrẹnsi bi ãdọta pọnun sinu apo rẹ̀, o sin i jade, bi nwọn ti mã yọ si ita gãn ni nwọn wo iwaju ti ogunlọgọ enia nbọ ti awọn ti ada, ibọn, kumọ, ọ̀lùgbọ́ndóró, nwọn nbọ wa bo ile ti awọn mejeji wa, ọba ti paṣẹ ki nwọn wó ibẹ kanlẹ patapata ki nwọn de Ẹsan-mbọ wa fun on ṣugbọn ki nwọn so ẹṣẹ Alabapade mọ ẹṣẹ ẹṣin on nla kan ki ẹnikan mã gun ẹ̀ṣin nã ki nwọn fi ori rẹ̀ wọ́ ilẹ kakiri ilu titi o fi mã ku, jọwọlọ bẹ̃ ni ki nwọn wa gbe e fun on.

Ṣugbọn igbati Alabapade kọja awọn ti ọba ran nwọn ko mọ pe on ni, ṣugbọn nwọn wọle nwọn mu Ẹsan-mbọ, nwọn de ọwọ rẹ̀ si ẹhin gẹgẹ bi aṣẹ ọba, nwọn ko ri Pade, nwọn wó gbogbo ile nã kanlẹkanlẹ, nwọn pa gbogbo ẹran, nwọn pa adiẹ ko si si ohunkohun ti nwọn da si láì bajẹ.

Igbati nwọn de ãfin ti nwọn ko ri Alabapade mu bọ inu bi ọba, ṣugbọn o bi i bẹ̃ lasan ni, ko si nkan ti o le ṣe. Lẹhin ti o bú Ẹsan, bú u, bú u, bú u tan, o paṣẹ ki nwọn lọ fi i sinu iyãra kan ti o ṣokunkun, ti o jẹ pe ferese kan ṣoṣo ti o wa nibẹ fẹrẹ má ju oju akengbe kekere kan lọ. Ibẹ l'o ni ki o mã gbe, o le riran ri onjẹ ti nwọn ba wa gbe fun u ni, ko si nkan ti o





le ri ju bẹ̃ lọ, ọba si paṣẹ pe ẹnikẹni ko gbọdọ tanna si iyãra nã lọsanloru titi aiye.

Bayi ni ipo ti ọba fi iyawo yi si, iyawo rẹ̀ ti o dara bi ẹja inu omi, iyawo rẹ̀ ti o jẹ olododo de gongo, o nfi ẹkun ṣe onjẹ lojõjumọ.

Ṣugbọn ọba mã nrin kiri ẹhin ile gbogbo ní on nikan lãrin oru nigbati gbogbo enia ba ti sun tan ti ẹnikẹni ki iri i. O wa di oru ọjọ kan ti ọba de ẹhin iyãra yi gãn l'o gbọ ti Ẹsan-mbọ nsọrọ si ara rẹ̀ ti o ni "Iwọ Ọlọrun, mo ṣe bi nwọn ní Ọlọrun ẹsan ni ọ? Ẹsan wo l'o mã san fun Alabapade mi yi? Ti ó ba mi gbe fun odidi oṣu mẹfa ti ko sun lori ibusun kan pẹlu mi ri, ti ko ba mi ni ọrọ ìkọ̀kọ̀ kan, ti ẹnikẹni ko gbọdọ gbọ! Láì ṣe ibi, ti nwọn lé jade kuro ni ilẹ yi? Dajudaju Pade yio jere iṣẹ rẹ̀ ni ode ọrun, Okonko yio jere tirẹ̀ nã bẹ̃, ṣugbọn ki nwọn to fi aiye silẹ nkọ? Iwọ Ọlọrun mi, ki nwọn to kuro lãrin awọn ọmọ enia nkọ, iwọ Ẹlẹda mi? Ọna wo lode aiye ni mo mã fi le san õre ti Alabapade ṣe fun mi. Olodumare, temi mà dọwọ rẹ o, Òyígíyigì temi mà dọwọ rẹ o, Ọlọrun ọrun, temi mà dọwọ rẹ o" ati bẹ̃ bẹ̃ lọ.

Gbogbo ọrọ wọnyi ni Ọba fi eti silẹ ti Ọba gbọ patapata. Ẹsan-mbọ ko mọ pe ẹnikẹni ngbọ ọrọ on. O sọ tirẹ̀ ṣa ni.

Igbati o di owurọ ọjọ keji, ọba ranṣẹ ki nwọn lọ pe Ẹsan-mbọ wa. Igbati o de, ara rẹ̀ ti yipada, o funfun háíhái bi ara olokunrun nitori ko jade ninu iyãra yi ri, ibẹ ni nwọn ngbe onjẹ wa fun u, ibẹ ni nwọn ngbe omi wa fun u, bi o ba si di pe o nfẹ ṣe igbọnsẹ, nwọn a gbe nkan ti yio ṣe e si wa, bi o ba ṣe e tan nwọn a gbe e lọ. Igbati ọba wo o, anu ṣe e, o bẹrẹsi ibẽre o ni, "Eyini ni pe iwọ ati ọkunrin nã ko sun pọ ni busun kan titi?" Ẹsan-mbọ ni, "Tani sọ fun yin?" O dahun o ni, "Mo gbọ ni." Ẹsan-mbọ tun bẽre o ni "Mo ni bawo l'ẹ ti ṣe gbọ sẹ?" Ọba nã fesi, "Mo sa gbọ ni."

Ẹsan-mbọ ba gbe oju soke o ni "Iwọ Ọlọrun, temi mà dọwọ rẹ o, o mọ pe ọkunrin yi ko sun si ori ibunsun mi ri, o mọ ọrọ ti imã sọ leti mi lemọlemọ nigba gbogbo "Ọlọla l'o ni ọ—A nilati bọwọ fun ọlọla. O mọ ọkunrin yi, ni aláìṣẹ̀ ki nwọn to le e jade. Temi mà dọwọ rẹ o hìì hìì hìì hìì—o bu s'ẹkun."

Omi bọ loju ọba pãpã. Ọrọ ti o si sọ ni yi. "Ẹsan-mbọ, lati oni lọ, mo yọ̃da fun ọ ki o jade ni ãfin yi ki o wa Alabapade yi lọ. Bi o ba ri i, mo fẹ ki o fẹ ẹ, ki o fi i ṣe ọkọ rẹ, ṣugbọn ki ẹ wa ki mi ni ãfin yi, ki nnawo igbeyawo fun yin. Ẹ wọle ki ẹ gbe apoti aṣọ jade, ẹ ko o fun Ẹsan-mbọ, ẹ wọle ki ẹ gbe owo fun u ti yio to fun irinajo yi. Ẹsan-mbọ, lọ, wẹ̀, fi nkan pa 'ra, kun atike, ṣe itọju ọwọ, ṣe itọju ẹsẹ, jade bi iyawo ẹni pataki, jẹun dãdã, mu iranṣẹ-kunrin lẹhin, mu iranṣẹbinrin lọwọ, ki ẹ wa ọkunrin nã lọ."

Ọrọ ti ọba yi wa sọ ti dun mọ Ẹsan-mbọ ninu ju ohun ti o le fi ẹnu sọ. Lọna kini, ko sọ pe on tun mã fẹ ẹ mọ, o fi i silẹ bi o ba fẹ ki o lọ fẹ ẹniti o wu u. Alabapade si ti wa lọkan rẹ tẹlẹtẹlẹ pupọ ri, àì le fẹ ara wọn ko ju ti ọba ti awọn mejeji nro lọ.

O wa ku ati ri Alabapade. Owo ti Ọba gbe fun Ẹsan-mbọ lati fi wa a lọ ko din ni apo mẹwa, o si fi ọpọlọpọ iranṣẹ le e ki nwọn jọ mã wa a. Nwọn wa a fun odidi ọdun kan nwọn ko ri i, gbogbo ẹniti nwọn ba si ri ti nwọn ṣe iwadi lọwọ rẹ̀ apejuwe ti nwọn nṣe ni pe o ti ku. Ẹnikan ti o wa ri wọn gbẹhin ni o ba gbogbo nkan nã jẹ o ṣe ibẽre pupọ nipa Alabapade ti o fi han gbangba pe ó mọ ọ on l'o tilẹ darukọ rẹ̀ ki nwọn to da a o ni, "Ṣe ẹniti nwọn npè ni Alabapade ni?" Nwọn ni hãn, o ni o dun on pupọ pe o ti ku. Ẹkun ni Ẹsan-mbọ bu si.

Nwọn ba pada nwọn nbọ ni ile. Mọto ni ọba gbe fun wọn ti nwọn ngbe kiri ibiti nwọn si ti gbọ ti iku Alabapade yi jina pupọ. Irin ọjọ marun dãdã si ilu Ọba Okonko ni.

Ni ọjọ kẹta ti nwọn ti npada bọ ti nwọn de ilu kan, ile ni nwọn tọrọ wọ̀ ti nwọn sun si, ko si ile ero ti enia le ti sun. Igbati o to bi agogo mẹjọ alẹ ni ariwo dede sọ ni agbala ile ti nwọn dé sí pe ẹnikan daku. Gbogbo enia ba dà gĩri lọ Ẹsan-mbọ nã lọ. Igbati nwọn si de agbala ti ariwo ti ta yi, nwọn ri ọkunrin nã bayi ti nwọn npe e ti nwọn nfẹ́ ẹ ti nwọn nni "Pade", "Pade" "Pade", ko ye ẹnikẹni ẹniti Pade yi jẹ nitori aisan ti o ti de si i, o ti rù, o ti gbẹ bi ẹja palapálà. Ẹsan-mbọ nã yọju wo ẹni nã o sa pada ni. Ibiti onile nã ti wa nṣe alaye fun wọn nipa aisan ti o de si ọkunrin yi, l'o ti darukọ rẹ tan





pe "Alabapade" ni ti o si ṣe apejuwe rẹ̀ ti o ṣe e de ibi orukọ Ẹsan-mbọ ti ko kuro lẹnu ọkunrin nã titi o fi daku yi.

Nwọn sa pe e, o ji, igbati o ṣe Ẹsan-mbọ tun lọ wo ọkunrin nã dãdã. Lõtọ, Alabapade ni. O ba pe e o ni, "A—la—ba—pa—de!" Ọrọ yi ta si Alabapade leti gere, o wo oke, Ẹsan-mbọ ní, "Emi Ẹsan-mbọ ni." Gau ni Alabapade ṣe gá-ńtá gá-ńtá dide. Ẹsẹ rẹ̀ ko ran ilẹ ju bẽ lọ mọ. Bẽni o gbe ọwọ rẹ̀ tinrin ti ko ni ẹran mọ kọ ọrun Ẹsan-mbọ, omi bọ loju awọn mejeji.

Were Ẹsan-mbọ ti lọ wa awọn Dokita pataki. Ni ọsẹ kan ara Pade ti gbọ̀nnù igbati o mã to ọsẹ meji o ti di bi ti atijọ. Iyalẹnu l'o wa jẹ fun u nigbati Ẹsan wi fun u pe o nilati fi oju kan Ọba Okonko.

Ki a má sa fa a gun lọ bi ilẹ bi ẹni, Alabapade ati Ẹsan-mbọ fẹ ara wọn. Ọba Oko-nko fun wọn ni owo rẹpẹtẹ, Alabapade tun bẹrẹ òwò ṣiṣe, owo nbi si i, ó nbi si i, ó nbi si i tobẽ ti o fi jẹ pe iba diẹ ni ọba pãpã fi ni owo ju wọn lọ.

Ẹ o ri i nisisiyi pe, gẹgẹ bi mo ti sọ ni ibẹrẹ, ohun gbogbo l'o ni ẹsan. Bi Alabapade ti ṣe ara rẹ̀ nipa iyawo ọba l'o jẹki o di ẹniti nfẹ iyawo nã gbẹhin, on l'o tun sọ aiye rẹ̀ di dãdã.

# ỌJỌ KEJI NINU ILE MỌGAJI ẸNUDUNJUYỌ

Igbati Mọgaji ile Ẹnúdùnjuyọ̀ ti sọrọ wọnyi tan, gbogbo enia tuka, olukuluku lọ si ile rẹ̀ nireti ati pada lọjọ keji.

Ni owurọ ọjọ keji, gbogbo ile nã ti kun fun awọn enia ti nwọn wa lati gbọ ọrọ ẹnu ọkunrin nã si i. O pẹ diẹ ki o to de lọjọ nã, nitori agogo mẹwa-abọ gẽre l'o de si gbangba. Lọjọ yi ọkunrin nã wọ aṣọ pupa ti o kan a ni ọrun ẹsẹ, o fi ọja funfun gba ori, o wọ salubata ti a fi awọ ẹ̀kùn ṣe nwọn si tẹ awọ ẹranko kan bayi niwaju rẹ̀, ẹranko nã jọ amọtẹkun ṣugbọn ki iṣe amọtẹkun gãn.

Igbati ọkunrin nã joko tan o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni:

"Ẹ ku ijoko o, gbogbo ọmọ Ajedubulẹ. Lana, mo ba yin sọrọ le ori èrè ti olukuluku ọmọ enia nilati jẹ bi ó fẹ bi ó kọ̀. Ẹniti o huwa rere mã jere rere, eyiti o hu buburu, mã jere buburu, ko si bi enia ti ṣe le gbin ọgẹdẹ ki orombo hu dipo ọgẹdẹ, tabi ki enia gbin ànàmọ́ ki ẹgusi hu jade, ohun ti ọmọ enia ba gbin ni ọmọ enia yio kore bi aiye yipada ti o di ọrun. Eleyi ni mo fẹ ki ẹ di mu gbagidi ninu gbogbo itan ti mo sọ fun yin lana.

"Loni, mo fẹ rán yin leti ọlá ti Olodumare fi fun ọmọ enia, mo si tun fẹ fi han yin bi o ti jẹ pe ọla yi tobi gidigidi ti o si jẹ pe o ṣoro fun ni lati lò. Ọla ti mo nwi yi ni agbara ironu ti enia ní ti o tayọ ti awọn ẹda iyoku patapata. Ẹ kiyesi ẹranko inu igbo ti a npe ni ẹtu, awọn ẹya Yoruba miran npe e ni olúbe. Bi ẹranko yi ba ti ri eso igi ti Ọlọrun wipe ki o mã ja jẹ́, o pari, ẹtu ko jẹ làkàkà lati kọ bi a tĩ gbin igi ti o ni eso wọnyi ki o ba mã ri i ka jẹ lakoko lakoko. Bayi ni igbesi aiye awọn ẹda yoku ri, onjẹ ti adaba njẹ lati ọjọ ti adaba kini ti de inu aiye nã ni iran adaba njẹ di oni, ko si iyipada ninu onjẹ aparo, adiẹ ti aṣadi ti njẹ lati aiyebaiye nã ni aṣadi nle kiri di oni, agbọnrin ko fi ewe ila silẹ ri, bẹ̃ni kọlọkọlọ ko pa irin ẹsẹ rẹ̀ da, adan ndorikodo sun lailai, owiwi nkigbe kiri lãrin oru, ọkẹrẹ nló mọ itakun kiri, ẹdun ati ijimere, inaki ati ọbọ,





gbogbo awọn wọnyi fi ori igi ṣe ile, nwọn a mã bẹ lati ọkan de ọkan.

"Ṣugbọn enia, enia, enia, enia ko le duro jẹ̃, inú rírò ko njẹki enia le simi. Bi a ba wo o dãdã a o ri i pe anfani ti Ẹlẹda fun enia yi ni ko njẹki enia simi titi ọjọ iku. Tani ninu yin ti o le fi ọwọ sọ aiya pe on ni itẹlọrun ninu aiye on. Ko si, o da mi loju pe ko si. Bi a ba ro o ni ọna kan a o wipe ko si, ṣugbọn bi a ba tun ro o lọna keji a le wipe o wa. A le wipe ko si, niwọn igbati o jẹ pe ipo kipo ti ọmọ enia ba wa laiye, a mã fẹ ki ipo on tun ga si i, bi enia ba nfi ọna kan ṣe nkan a mã fẹ ki on tun ṣe atunṣe si ọna nã ki o tubọ dara, ko si ẹniti o nlepa owo ti o jẹ gbà pe eyiti on ni to ni ọjọ kan, bi enia ba si ńṣòwò a fẹ ki òwò on mã ga titi lailai ni. Idi aini-itẹlọrun ni eyi. Ṣugbọn enia tun le wo o lọna miran wipe ki ipo ti enia wa tẹ ẹ lọrun nipa pe ki on pãpã gba pe bi ipo nã ba le ga si i ki o ga si i, ṣugbọn pe bi ko ga si i ki ó má mi on l'ọkan ki enia wà ki ó má ni ọkanjuwa eyini ni pe ki o ni itẹlọrun si nkan ti ara rẹ̀ ki ti ẹlomiran má wọ ọ loju, iru eleyi ni itẹlọrun ti a nwi. Ẹ o ri i pe enia le ni itẹlọrun lọna kan pataki ti o jẹ pe bi ko tilẹ ni i ni ọna miran, a o gba pe o ni itẹlọrun. Bi ipo enia ba tẹ ẹ l'ọrun ṣugbọn ti o nwa ọna ati mã ṣe ohunkohun ti on nṣe ki o dara ju bẹ̃ lọ, o ni itẹlọrun nã ni.

"Aini itẹlọrun nipa owo l'o wọpọ ju, ko si si nkan ti awọn ẹlomiran ko le ṣe lati ri owo. Afi bi a ba npurọ ni a o wipe owo ko ṣe pataki ninu aiye, ṣugbọn sibẹ, o ni ibi ti pataki owo mọ. Owo ko to enia rara ko si to ẹmi ẹni. Ọpọlọpọ enia ni ode aiye yi ni nwọn ti sọ ara wọn di yẹpẹrẹ nitori owo, nitori owo, nwọn a sọ ara wọn di eleke, omiran a ti ipa bẹ̃ kọ ipakọ si Ọlọrun Ọba. Igbati mo ba sọ itan yi fun yin ni ẹ o mọ nkan ti nini-itẹlọrun jẹ, ati ibiti ọmọ enia le fi ara rẹ̀ si nitori owo, bayi ni itan nã lọ:

"Ọkunrin kan wa ni aiye atijọ, orukọ ẹniti njẹ Kòtẹ́milọ́rùn. Baba ati iya Kòtẹ́milọ́rùn l'owo to ibiti ọmọluwabi lè l'owo de, nwọn si ran a lọ si ile iwe, nwọn kọ ọ, o jina kõro igbati o mã pari ẹkọ rẹ̀ nwọn fun u ni ile pẹtẹ̃si kan nwọn si ra mọto ayọkẹlẹ kan fun u pẹlu, ko si nkan ti o le jẹ ẹ ni iya, ẹgbon

rẹ̀ agba ọkunrin ti nwọn bi tẹle baba rẹ̀ l'owo bakannã, ko si si nkan ti o le bẽre ti ko ni ṣe fun u.

“Sibẹ ọkan Kòtẹ́milọ́rùn ko balẹ nitori lọna kini, baba ọkan ninu awọn ọrẹ rẹ̀ l'owo ju baba ti on lọ eleyi kò tẹ ẹ lọrun, ati pãpã ti o tun jẹ pe ọrẹ rẹ̀ yi mọ iwe diẹ ju u lọ. Nitori eyi inu rẹ̀ ko dun, igbati o si tilẹ̀ ṣe, ko si ẹrin lẹnu rẹ̀ rara mọ, bi o ba nlọ ki oju rẹ̀ le kórókóró ni. Igbati o ṣe, baba rẹ̀ ku, igbati nwọn si yẹ iwe akọsilẹ baba rẹ̀ wò, owo ti o fi silẹ jẹ ãdọtalẽrugba apo, igba ninu eleyi jẹ ti Kòtẹ́milọ́rùn, ile mẹfa jẹ tirẹ̀, bẽ na si ni ilẹ̀ pupọ jẹ tirẹ̀ pẹlu ninu ogún ti baba rẹ̀ fi fun u.

Ko wa pẹ lẹhin eyi, ti iya rẹ̀ ku ti o tun fi iba ohun ti on nã ni silẹ fun u. Nisisiyi Kòtẹ́milọ́rùn pãpã ti wa ni to ãdọtalerugba apo owo dãdã o si pinnu lati fi eleyi ṣòwò. O bẹrẹ, òwò nlọ dada, owó nwọle, ó tubọ nwọle si i, igbati o si fi mã to ọdun meji, o ni irinwo apo dãdã.

“Igba yi ni baba ọrẹ rẹ̀ kü, igbati nwọn si mã ka akọsilẹ baba nã, ẹgbẹta apo owo l'o fi silẹ fun u. Ibanujẹ wa wọ Kòtẹ́milọ́rùn l'ẹ́wù o si pinnu ati wa owo de ibikibi ti o le ri i ati ni ọna k'ọna ti o le fi wa a.

“Nigbati o ṣe, o pinnu ati wa ọna ati lo ẹmi eṣu lati ri owo, o ba tọ agbalagba ọkunrin kan bayi lọ ti gbogbo enia mọ ni olori ẹgbẹ oṣo ati ajẹ ni agbegbe ibẹ o ko, o ro fun u bi on ti nwa owo to ti on si pinnu lati wa owo de ibi kibi ti on le wa a de ati lati lo ọna k'ọna ti enia le gba ri i.

“Ọkunrin yi dakẹ fun igba diẹ ko sọrọ. Igbati o si mã sọrọ o ni ki o mã lọ ni akoko nã ki o tun pada wa si ọdọ on ti o ba ṣe.”

Ni ọjọ keji, Kòtẹ́milọ́rùn lọ. Igbati o de ọhun ti ọkunrin nã bẹrẹsi sọrọ ẹru ba ni o ni,

“Ọmọ mi, bi o ba nfẹ owo, ko ṣoro, ṣugbọn nkan ti o nilati ṣé ni ó ṣoro. Lọna kini, o nilati kọ ẹhin si Olodumare ki o kọju si eṣu ọba Ọrun Apãdi, alakoso gbogbo ijamba aiye. Olotu Ijangbọn ãrin ọmọ enia, Àṣìtánì, Bilisi, ẹniti o ní gbogbo ija, asọ̀, ibanujẹ, òṣé, ati ẹkún awọn ọmọ enia ni ikawọ rẹ̀. O ó fi oju rẹ ri Eṣu oluwa mi bayi, o ó fi ẹnu rẹ ṣãta Ọlọrun Ọba niwaju rẹ̀, o ó gba a gẹgẹ bi ọga rẹ, o ó si wa ṣeleri ẹmi





‘O ba tọ agbalagba ọkunrin kan “ bayi ” lọ ti gbogbo enia mọ ni olori ẹgbẹ oṣo ati ajẹ ’

rẹ fun u pe, igbakigba ti o ba fi aiye sile, ọ̀dọ̀ rẹ̀ ni ẹmi rẹ nlọ. Gbogbo iwọnyi l'o ó ṣe. Nitori eyi, mo fẹ ki o lọ ronu dãdã ki o pada wa sọ fun mi bi o ó ba le ṣe eyi tabi o ko ni le ṣe e."

"Bayi ni ọkunrin na wi, Kòtẹ́milọ́rùn nã gbọ ọ́ dãdã, o jade, o lọ si ile.

"Igbati ó di ọjọ keji ti Kòtẹ́milọ́rùn de, ọkunrin yi wí fun u ki o pada lọ si ile ki o ronu ọrọ ti on ba a sọ fun odidi ọjọ meje gbako.

"O tun lọ. Igbati ọjọ meje pe, o pada. Ọkunrin yi wa bi i o ni, 'Bawo l'o tí ro ọrọ ti mo ba ọ sọ si?' On nã dahun o ni, 'Mo ti ro ó tan, mo fẹ lati ní owo lọnakọna ti mo ba ti le ni i.' O tun bere o ni, 'O ṣetan lati kọ ẹhin si Olodumare, Ẹlẹda rẹ?' Kòtẹ́milọ́rùn fesi o ni 'Mo ṣetan.' O tun bẽre, 'O ṣetan lati fi ẹmi rẹ fun Eṣu, oluwa mi, Alakoso Ọrun Apãdi, ni gbogbo aiye rẹ ati lẹhin iku?' Kòtẹ́milọ́rùn dahun o ni, 'Mo ṣetan patapata.' Lẹhin eleyi ni o to wa sọ fun Kòtẹ́milọ́rùn nkan ti o nilati wa. O nilati wa oriṣi ohun ọ̀sìn meje ki ọkọ̃kan ninu wọn jẹ funfun báláú. Eyini ni pe bi o ba mã mu ewurẹ wa, ki gbogbo ara ewurẹ funfun, bi o ba ri aguntan, ki gbogbo ara aguntan nã funfun, ki o sa wa oriṣi meje bẽ, ki o wa obi ifin meje, orogbo meje, ati ọkọ̀ atãre meje. Ki o wa ge ọpa aṣọ funfun meje tabi mẹrinlã ki o fi da ẹwu, ṣokoto ati fila ki o lo gbogbo rẹ̀ tan. Bi ọpa meje ba to o lati lò, meje ni yio wa, ṣugbọn bi meje ko ba to, ó nilati lo gbogbo ọpa mẹrẹrinlã tan nitori ẹnikẹni ko gbọ̀dọ ba a lo o.

"Kòtẹ́milọ́rùn wa gbogbo nkan wọnyi tan patapata.

"Igbati gbogbo rẹ̀ wa pe wayi ni o ko gbogbo rẹ̀ o di ile ọkunrin yi. Onitọhun gbe awọn ohun wọnni o ko wọn lọ, o wa wi fun Kòtẹ́milọ́rùn ki o wa si ile on ni agogo mọkanla-abọ alẹ ọjọ kan, ki o wa pẹlu aṣọ funfun ti o ti da ki o wọ wọn s'ọrun.

"Kòtẹ́milọ́rùn de ni wakati ti o wi lõtọ gẹgẹ bi o ti fi aṣẹ fun u pe ki o wa. Iyalẹnu gbã l'o jẹ fun u pe ko ri ẹyọ ẹnikan ninu ile nã mọ, awọn obinrin ti ọkunrin yi ni ti jade ninu ile, awọn ọmọ rẹ̀ ko si nibẹ, ko si ẹyọ ẹnikan afi on. Igbati o wọle, o ba ọkunrin yi ni ode, igbati o ṣe, ọkunrin nã yi wọle. Igbati o wa mã jade lati iyãra wa, agogo mejilã oru lu gãn ni, o ti





yi pada patapata. Mariwo l'o bo o lara de ilẹ ko, gbogbo ara rẹ̀ kun fun kiki ẹjẹ, oju ti yipada o pupa rẹ̀bẹ̀tẹ̀. Ko sọrọ bi enia mọ, ṣe l'ó nmi soke sodo lẹ̃kọkan, ṣe l'o si ńmì siwa mì sẹhin bi ẹni pe ko si ifun ninu mọ ati bi ẹni pe o mã fò bi ẹiyẹ. Ọwọ l'o jù si Kòtẹ́milọ́rùn pe ki o bọ siwaju ni on nã ba bọ siwaju, igbati nwọn jade ninu ile tan ni ọkunrin yi to tun wa bọ siwaju ti o nrin bi o ti nmì tíé tíé lọ. Ọsupa dabi ọsan, Kòtẹ́milọ́rùn wà ninu aṣọ funfun, ọkunrin nã wà ninu mariwo ọpẹ opopo dá gírogíro, nwọn ko ri ẹyọ ẹnikan bẹ̃ni ẹyọ ẹnikan ko ri wọn bayi ni nwọn ṣe titi nwọn fi jade lãrin ilu patapata. Lẹhin bi iṣẹju mẹwa lẹhin eyi, ti nwọn ti ntọ oju ọna oko kan lọ ni ọkunrin nã ya si ọna kekere kan bayi ti Kòtẹ́milọ́rùn nã yà ti i. Igbati o fi mã to ọgọrun ẹsẹ ṣe ni ọna yi di titobi ti nwọn gbá a ti o mọ tónítóní, peregun ti nwọn gbin ni ẹsẹ mẹta mẹta si ara wọn wà ni apa ọtun ati apa osi ọna nã bi nwọn ti nlọ. Igbati o pẹ diẹ, dipo peregun, igi òkikà ni nwọn gbin si ẹba ọna. Igbati o si mã tun ṣe, igi akòko l'o dipo òkikà wọnyi, eleyi ko duro ju igba ẹsẹ lọ ti o fi pari ti nwọn de ibiti o tẹju pẹrẹsẹ kan bayi lọ ni eteti eyiti ijoko kẽkẽkẽ ti o dabi ijoko awọn ti nta ẹkọ lọja lọ wa. Ko ga to aga rara.

"Igbati nwọn de ọhun, pupọ ninu awọn ijoko wọnyi ni awọn ẹiyẹ nla nla gbogbo bà le, iyẹ wọn ko kuku funfun gbõ ṣugbọn o dabi aṣọ funfun ti ó kun fun ẽri ti o npọn ràkọ̀-ràkọ̀.

"Ko pẹ pupọ ti nwọn de ọhun ti ẹniti o mu Kòtẹ́milọ́rùn wa nã dede yipada ti o di ẹiyẹ, bi o si ti di ẹiyẹ bayi ti Kòtẹ́milọ́rùn ro pe on nikan ni enia ti o joko, ni o wo iwaju ti o ri i pe ki iṣe on nikan ni on wa ni enia, ó rí to bi awọn marun miran ti nwọn wọ aṣọ funfun ti nwọn ko sí ni ipo ẹiyẹ. Awọn ti o ṣẹṣẹ wa ni wọnni.

"Igbati o ṣe ni ọkan ninu wọn ke ni ohun gõro. Kike ti o ke yi, ṣe ni gbogbo awọn ẹiyẹ wọnni yi pada ti nwọn di enia."

"Ọkan ninu wọn ba dide ti o dá orin kan bayi, bi o ti da a ni gbogbo wọn gbe orin nã lọ yùn-ùn. Nwọn kọ orin yi fun igba diẹ ni ọkan ninu wọn dide ti o bẹrẹsi ọfọ̀ pipe, o pe ọfọ̀, pe ọfọ̀ pe ọfọ̀ titi.

"Ibiti o ti npe ọfọ yi afi igbati itan enia kan dede ja silẹ lati oju ọrun. O tun npe ọfọ lọ, igbati o ṣe, itan miran tun ja,

on nã kò dakẹ, o npe ọfọ̀ lọ. Igbati o pẹ, apa ja silẹ, ẹsẹ ja, ọwọ ja, ọrun ja, igbati ori ja silẹ afi igbati gbogbo wọn di pọ ti nwọn di ọkunrin kan. Ọkunrin nã ba ni lẹru gidigidi. Ibi ipakọ rẹ̀ tẹ̀ kọngọ o dabi idi ọpa itilẹ on papa ga fio fio o si tun sanran, o wọ yẹ̀rì mariwo ọpẹ o si fi mariwo ṣe ẹwu. Oju meji nla nla ti o ni to ẹ̀ṣẹ́ ọwọ o ndan yinrinyinrin bi irawọ, ẹnu rẹ̀ ṣe bi ẹni tobi, ṣugbọn mo ro pe ètè rẹ̀ ti o nipọn ni o jẹki o dabi ẹni pe ẹnu tobi ju ni, nitori bi a ba fi wọn bi on pãpã ti tobi to, a ko le wipe ẹnu rẹ̀ tobi jù lọ. Ehin ọkunrin nã ta si ode, ètè kò bo o tan, o si wa hu iyẹ nla ti o yọ jade ninu apa mejeji ti mariwo ọpẹ bo. O wọ bata irin si ẹsẹ ori bata nã dabi ẹsẹ pẹpẹiyẹ. Ẽkan ọwọ ẹda yi dabi ti awodi o tobi o si nipọn.

"Bi apa ati ẹsẹ ti tò jọ ti nwọn di enia tan, ni tabili nla kan jade lati inu ilẹ pẹlu aga kan. Iwe nla kan wa ni ori tabili yi.

"Ẹda yi ba joko le ori aga o ṣi iwe nla nã o bẹrẹsi pe orukọ. Bi o ti npe orukọ wọnyi ni o nṣe ibẽre ọpọlọpọ nkan ti o si nṣe ileri onirũru gbogbo. Ibẽre ti o ṣe lọwọ awọn mẹfa ti ó kọ́ pe ni a o sọ yi a o fun olukuluku wọn ni orukọ Lamọrin a o si wa to wọn lẹsẹsẹ bi a ti ika iṣiro owo, a o pe ẹni kini ni Lamọrin Kini, ẹni keji, Lamọrin Keji, ati bẹ̃ bẹ̃ lọ. A o pe ọkunrin nã ni Alaga. Bayi ni ibẽre nã gbogbo lọ:

| | |
|---|---|
| *Alaga:* | Iwọ ni Lamọrin Kini? |
| *Lamọrin:* | Bẹ̃ni. |
| *Alaga:* | A bi ọ ni ọjọ 2 oṣu June, 1922. |
| *Lamọrin:* | Bẹ̃ni. |
| *Alaga:* | O ti kọ Olodumare silẹ patapata? |
| *Lamọrin:* | Bẹ̃ni. |
| *Alaga:* | O gba mi dipo Olodumare. |
| *Lamọrin:* | Bẹ̃ni. |
| *Alaga:* | Ta l'o ni emi rẹ lẹhin iku? |
| *Lamọrin:* | Ẹnyin. |
| *Alaga:* | Tani mi? |
| *Lamọrin:* | Ẹnyin ni Alaiyeluwa, Eṣu, Ẹlẹ́gbára, Ọba Ọrun Apãdi, Alakoso ogun, Alakoso ọ̀tẹ̀, Alakoso rogbodiyan aiye gbogbo. Ẹnyin ni olotu ijamba, olotu ijangbọn, olotu ibanujẹ aiye porogodo. |
| *Alaga:* | Ṣe o ye ọ kedere, o da ọ loju ṣaka ṣaka pe o ko ni ipin ninu Ọrun Afẽfẹ rere lẹhin iku ati pe Ọrun Apadi ni tirẹ? |
| *Lamọrin:* | O da mi loju. |
| *Alaga:* | Ọjọ iku rẹ ku ọdun melo? |
| *Lamọrin:* | Ogun ọdun ni, gẹgẹ bi akọsilẹ iwe ọwọ Iku ti wi ṣugbọn ẹ ti sọ pe ẹ o fẹ tete mu mi lọ ni ipade ti a ṣe kẹhin ati pe ẹ fẹ ge marun kuro. |
| *Alaga:* | Bi mo ba wi bẹ̃, mo ti ge e, mo ti ge e kuro ni eyini, o wa ku melo ni mo ñbi ọ? |
| *Lamọrin:* | O ku mẽdogun. |
| *Alaga:* | Kini mo fun ọ gbẹhin? |
| *Lamọrin:* | Ẹgbẹrun apo owo. |
| *Alaga:* | Kil'o nfẹ loni? |
| *Lamọrin:* | Ẹgbẹrun apo lọna ẹgbẹrun ni. |
| *Alaga:* | Mã lọ, yio ri fun ọ gẹgẹ bi ibẽre rẹ. |

Bayi ni Alaga yi pari ibẽre ti Lamọrin Kini, o wa kan Lamọrin Keji. Bayi ni ibẽre tirẹ̀ lọ:—

| | |
|---|---|
| *Alaga:* | Iwọ ni Lamọrin Keji? |
| *Lamọrin Keji:* | Bẹ̃ni. |
| *Alaga:* | A bi ọ ni ọjọ kẹfa oṣu keje ni ọdun 1931. |
| *Lamọrin Keji:* | Bẹ̃ni. |
| *Alaga:* | O ti gba mi gẹgẹ bi oluwa rẹ? |
| *Lamọrin Keji:* | Bẹ̃ni. |
| *Alaga:* | O ti kọ Olodumare silẹ. |
| *Lamọrin Keji:* | Bẹ̃ni. |
| *Alaga:* | Tani oluwa ẹmi rẹ lẹhin iku? |
| *Lamọrin Keji:* | Ẹnyin. |
| *Alaga:* | O mọ ẹniti mo jẹ? |
| *Lamọrin Keji:* | Dãdã. |
| *Alaga:* | Njẹ sọ orukọ mi. |

*Lamọrin Keji :* Ẹnyin ni Eṣu, Ọba fun ogunlọgọ ninu awọn ọmọ enia, Ẹlẹ́gbára, olori Ọrun Apãdi, Anjọnnu ti a fi iṣẹ èpè fun Anjọnnu, Ṣigidi ti o kọja gbogbo ṣigidi, Onílé iná, ẹlẹ́gbàawá atọ̀, ẹlẹ́gbàawá àdó, ẹlẹgbààwá ogede, alagbara lori dukia ode aiye gbogbo.

*Alaga :* O mọ ibiti ẹmi rẹ nlọ lẹhin iku tabi o ko mọ?

*Lamọrin Keji :* Mo mọ ọ dada, ọrun Apadi ni temi, ni iwọn igbati mo si ti kọ ipakọ si Ọlọrun Ọba o fihan pe Ọrun Afẹ̃fẹ rere ki iṣẹ temi mọ.

*Alaga :* Ẽlo l'o bẽre ni ipade ti a ṣe kẹhin?

*Lamọrin Keji* Nko tilẹ bẽre owo nigbana, orogun ti o nfẹ gba ọkọ lọwọ mi ni mo ni ki ẹ ṣe bi ọṣẹ ti iṣe ori.

*Alaga :* Ipo wo l'orogun nã wà nisisiyi?

*Lamọrin Keji :* Ihõho l'o nrin kiri ode, ko sun sinu ile mọ, búkà l'o nsun si, ati pãpã ó ti di adẹtẹ patapata.

*Alaga :* Kil'o nfẹ loni?

*Lamọrin Keji :* Owo.

*Alaga :* To bi ẽlo?

*Lamọrin Keji :* To bi ẹgbã pọnun ni.

Bi o ti wi bayi ni gbogbo awọn ti o wa si ipade kùn lọ hùn ùn, nwọn bẹrẹsi wipe ẹgbã pere, ẹgbã pere.

*Alaga :* Ẹgbã pere?

*Lamọrin Keji :* Ẹ kuku fi ṣe ẹgbãfa pọnun.

*Alaga :* Yio ri fun ọ bi ibẽre rẹ. Ọjọ iku rẹ ku ọdun melo?

*Lamọrin Keji :* O ku ọgbọn ti a ba ge marun ti ẹ fẹ lo kuro

*Alaga :* Mã lọ, mã j'aiye rẹ lọ.

Bayi ni ibẽre ti Eṣu ṣe lọwọ Lamọrin keji, o wa kan Lamọrin kẹta.

*Alaga :* Iwọ ni ọmọ mi, Lamọrin Kẹta?

*Lamọrin Kẹta :* Bẽni.

*Alaga :* A bi ọ ni ọjọ kẹrinlã oṣu July, 1932.





*Lamọrin Kẹta :* Bẽni.

*Alaga :* Tal'o fẹran ju ninu emi ati Ọlọrun?

*Lamọrin Kẹta :* Ẹnyin ni.

*Alaga :* Nitori kini?

*Lamọrin Kẹta :* Ọlọrun ko ni ojusaju kan, ẹnyin ẹ wo o, a rọ ojo si ori ẹni rere, a rọ si ori ẹni buburu, a ran õrun si ori ẹni rere a ran õrun si ori ẹni buburu, A fun ẹni rere l'ọmọ, a fun buburu. Ṣugbọn ẹnyin yatọ, bi mo ran yin si ọta mi, loni, ẹ ṣetan lati jiṣẹ fun mi bawo ni mo ṣe le ṣai fẹran yin.

*Alaga :* Ṣugbọn ṣe o mọ pe ẹmi rẹ di temi lẹhin iku rẹ?

*Lamọrin Kẹta :* Mo mọ dãdã.

*Alaga :* O si mọ pe a o jọ mã gbe Ọrun Apãdi ni.

*Lamọrin Kẹta :* Bẽni.

*Alaga :* Ọmọ mi, mo fẹran rẹ gãn. Ṣe o ko si gbagbe pe Ọrun Apãdi ko ri bi Ọrun Afẹ̃fẹ Rere?

*Lamọrin Kẹta :* Mo mọ bẹ̃, Ẹniti o ngbe Ọrun Apadi yio jiya titi aiye ainipẹkun, ti Ọrun Afẹ̃fẹ Rere yio wa ninu ayọ titi aiye ainipẹkun. Ṣugbọn, ṣe lẹhin iku ni. Emi fẹ gbadun ara temi ninu aiye yi nã. Ṣe ẹnyin yi nã sa wà ni ọrun kan, ọrun ti ẹ wa nisisiyi to fun mi lẹhin iku mi. Ẹ ṣe nkan ti mo ba nfẹ fun mi nisisiyi.

*Alaga :* Kil'o tilẹ nfẹ loni, sọ fun mi, ọmọ mi.

*Lamọrin Kẹta :* Nkan meji pataki ni mo nfẹ. Ekini, ẹgbẹrun apo owo lọna ọtalugba, Ekeji : Mo fẹ iku ẹnikan.

*Alaga :* Darukọ ẹni nã, si sọ ohun ti o ṣe fun mi.

*Lamọrin :* Tẹmẹ̀dò ni a npe e, nko ri i ri, nko mọ̀ ọ ri, emi rẹ̀ ko tilẹ jọ fa nkankan pọ ri, ṣugbọn o lokiki pupọ ju, pé ó l'okiki yi nbi mi ninu, o tan.

*Alaga :* Mo wà lẹhin rẹ ni gbogbo iwọnyi. Nipa ti owo, ṣe iwọ nã mọ pe eyini ko ṣoro fun mi, kio to de ile, owo ti o bẽre yio ti de inu iyara rẹ.

Nipa ti Tẹ̀mẹ̀dò, emi pãpã korira ọmọ enia ti Ọlọrun da si ori ilẹ aiye, mo korira pe ki ẹnikẹni lokiki. Ki aiye ẹnikẹni mã dara, ki nkan ẹnikẹni mã gún, jẹ ọpọlọpọ ibanujẹ fun mi, ṣugbọn ọgbọn ẹniti a npe ni Ọlọrun yi pọ, ọlọgbọn ẹ̀wẹ̀ ni, ọlọgbọn ṣọṣoro ni, ẹnikõkan ni ode aiye l'ó ti fi Angẹli Olusọ kan fun, ẹniti Angẹli Olusọ kan ba si nsọ ti oluwarẹ ko huwa buburu si ẹnikẹni, idà ọwọ Angeli nã a mã mu ju abẹ lọ Nitorina ṣe ni ki awa mejẹji pa ero pọ ki a wa ọna tí Tẹmẹdo yio fi ṣẹ wa ni ẹṣẹ kan, bi o ba ti ṣe bẽ, ẹnu ida Angẹli ti o nsọ ọ yio ku, emi nã yio wa lọ kó bi mejilã ninu awọn Angẹli abẹ mi ni Ọrun Apadi ti yio le ba Angẹli Olusọ Tẹmẹdo ja, dandan ni ki nwọn bori awọn mejeji. Dajudaju, a nilati mu Tẹmẹdo kuro ni ode aiye yi, o pẹ tan, ni ọsẹ mẹrin loni. Ọna ẹṣẹ ni a o wa fun u ki ẹnu ida ọwọ Angẹli ti nsọ ọ ba ku.

*Lamọrin Kẹta* : Ọga, nigbati ẹ ni ẹ ko fẹ ki ọmọ enia kan lokiki ni ode aiye, awa nkọ, ẹ ko fẹ ki awa na ni?

*Alaga* : Kil'o tun nbere yi, bi tiyin ni? Ṣe ọmọ mi ni ẹnyin, igbadun yin, lode aiye nikan ni, o si wà fun igba diẹ.

*Lamọrin Kẹta* : Kini ọrun ti awa nlọ tilẹ ti ri?

*Alaga* : Mo ti wi fun gbogbo yin ni igba pupọ, mo wipe ibiti emi wà ni, ìyà ni yio si mã jẹ ni, bi ongbẹ ngbẹ yin ẹ ko ni ri itẹlọrun bi ẹ tilẹ mu omi odo kan gbẹ, ebi a mã pa yin, ẹ o jẹun jẹun ẹ ko ni yo bi ẹ tilẹ jẹ gbogbo onjẹ aiye tan. Awọn iyà bi iru eyi ni yio mã jẹ yin, nitori ẹ ti jẹ onjẹ yin ẹ si ti mu omi yin lode aiye ẹ ti kọ ẹ̀hìn si Ọlọrun Ọba, ṣugbọn niwọn bi emi nã ti le farada iya wọnni njẹ ko yẹ ki ẹnyin nã le farada a dan?

"Bi o ti ṣe ibere yi, gbogbo awọn ti nwọn wa ni ipade l'o fi ohun kan dahun ti nwọn ni o yẹ.

*Alaga* : Ọjọ melo l'ó kù l'aiye fun ọ?

*Lamọrin Kẹta* : O ku ọgbọn ọdun fun mi bamubamu.





*Alaga* : Ṣe o ti yọ marun ti mo nyọ silẹ?

*Lamọrin Kẹta* : Mo ti yọ ọ.

*Alaga* : Mã lọ, owo nduro de ọ ni 'le bi mo ba si ti de ọrun ng o mã wadi ọna ti a o fi mu Tẹ̀mẹ̀dò olokiki kuro lãrin awọn ọmọ enia. Lẹhin eleyi ni Lamọrin kẹrin bọ siwaju Eṣu, bayi si ni ibẽre tirẹ lọ.

*Alaga* : Lamọrin kẹrin, mo woye pe o ko wa si ipade ti o kọja.

*Lamọrin Kẹrin* : Bẽni, oluwa mi.

*Alaga* : Ṣe ko si nkan?

*Lamọrin Kẹrin* : Ko si, ṣugbọn ọjọ nã ni mo fo lọ si ilu okẽre mo lọ mu ọmọ ara ile mi kan tí mo ṣe 'leri fun yin tẹlẹ pe ng o fi ta ipade lọrẹ.

*Alaga* : Ṣe o ri i mu?

*Lamọrin Kẹrin* : Kabiyesi, ko ṣẽ ṣe, diẹ l'o ku ki ntilẹ parẹ́ s'ọhun, Angẹli Olusọ rẹ le pupọ, mo rọju fo de ipade yi ni, ara mi ko tilẹ ti ile tan bayi diẹ l'o kù ki Angẹli nã ge iyẹ apa mi tan.

*Alaga* : O ma ṣe o. Jẹki nwọ iyẹ rẹ ná.

Bi o ti wi bayi ọkunrin yi tun ti yipada, o di ẹiyẹ, o ba fo wa siwaju Eṣu. Bi Eṣu ti fi ọwọ ba iyẹ apa rẹ diẹ ti o ku bayi, ṣe ni gbogbo iyẹ bọ́ ti ko ni iyẹ l'apa mọ. Afi were ti gbogbo wọn yipada ti nwọn di ẹiyẹ ti nwọn bẹrẹsi ṣa ẹiyẹ ti ko ni iyẹ lapa nã jẹ, nwọn sa pa a patapata. Nwọn ṣe eyi tan ni nwọn tun pada di enia ti nwọn joko si ipo wọn. Ẹiyẹ wà labẹ aga Eṣu, o ti ku patapata.

Nigbati ẹniti o mu Kotẹmilọrun lọ si ipade sọ idi rẹ ti gbogbo wọn fi pa Lamọrin Kẹrin bẽ o ni, "Ọna eke, ọna ole, ọna agabagebe, ọna orukọ bibajẹ, ọna iku, ọna arun, ọna irira, ọna wọbia, ọna ojukokoro gbogbo, ọwọ Eṣu l'ó wà, Alaiyeluwa, Ọba ọrun Apadi, ṣugbọn Eṣu ti o ri bayi, ko nfẹ ki ẹnikẹni purọ tan on jẹ. Ó nilati jẹ pe Lamọrin Kẹrin purọ fun Eṣu nipa ọrọ ti o sọ, o nilati jẹ pe ẹniti o ni on ba ja pe o fẹrẹ ṣẹgun on, ṣẹgun rẹ̀ gãn ni, o nilati jẹ pe iyẹ ti o fi fo wa si ipade, o wa a ya ni, bi bẽ kọ iyẹ nã ko ba ti bọ ni apa rẹ. Gbogbo awọn

ti o wa si ipade ni ọmọ ogun Eṣu ni ode aiye. Idi rẹ̀ ti gbogbo wọn si fi dimọlu pa ẹniti o tan ọga wọn jẹ ni eyi."

Arọ patapata gbã ni Lamọrin Karun ko si si ẹniti o le ri i loju aiye ti ãnu rẹ̀ ko ni ṣe, nitori igbati o wa ni ipo enia ẹsẹ rẹ̀ kajọ bi itakun titi de ibi ekiti idi, idi si tun kako o fẹrẹ má ṣẽ joko mọ, o ri gongo bi idi ọbọ, igbati o tilẹ tun yipada si ẹiyẹ, ara ẹiyẹ nã ko dan bi ara awọn iyoku o tun ri wọ́gọ wọ̀gọ. Bi enia ba ri i loju aiye, yio fẹrẹ sọrọ odi si Olodumare pe ko ṣe e dara to ti o fi jẹ pe o da eleyi ti o ni abuku ara to bi o ti ni i. Ṣugbọn nigbati enia ba gbọ ohun ti o sọ ninu ipade buruku yi, enia ko ni ṣai tun ba Olodumare pãpã yọ pe o da a bi o ti da a, nitori iba jẹ pe ko da a bẹ̃ ni, on iba ba iṣẹ ọwọ Ọlọrun Ọba jẹ pupọ nitori pupọ̀ ninu awọn ayanfẹ Olodumare ni iba pa lara. Bayi ni on ati Eṣu ti iṣe Alaga ijangbọn ṣe sọrọ si ara wọn.

*Alaga :* Lamọrin Karun, ọkunrin mẹta, alafia kọ?

***Lamọrin Karun :*** Alafia ni, oluwa mi.

*Alaga :* Njẹ ọdun ti ó kù fun ọ lode aiye ko to mẽdọgbọn bẹ?

***Lamọrin Karun :*** O ju bẽ lọ, ọgbọ̀n ni. Mo tilẹ ge marun ti ẹ nyọ kuro ni.

*Alaga :* Ṣe o ti yanju aburo rẹ, ọmọ orogun iya rẹ ti o sọrọ rẹ̀ ni ijọsi?

***Lamọrin Karun :*** Igba melo? Mo mà tilẹ mu lara ẹjẹ rẹ wa loni, o wà ninu àpò ẹ̀jẹ̀ mi.

*Alaga :* Ṣe nkan ti o nfẹ ki nṣe fun ọ ko pọ ju loni?

***Lamọrin Karun :*** Ko pọ rara ko ju mẹta lọ awọn ni iwọnyi—

***Ekini :*** Mo fẹ ki baba mi ku ki o to di ipade ti mbọ, mo si fẹ ki akọbi rẹ̀ ọkunrin ati obinrin ku pẹlu ki emi ba ri aye jogun baba mi, awọn ọmọ rẹ̀ mejeji l'o ju mi on nã ti pẹ ju laiye o to ki ó mã lọ.

***Ekeji :*** Mo fẹ ki oju ọrẹ mi ti a jọ nṣiṣẹ iṣọna fọ, ko jẹki nri iṣẹ ṣe to.

***Ẹkẹta :*** Mo fẹ apo owo marun, ki nfi apo kan ṣe oku baba mi, apo kan fun oku awọn akọbi rẹ̀ mejeji ti mo ti sọ. Emi nã yio mã fi apo mẹta yoku jẹun.





*Alaga :* Gbogbo nkan ti o bẽre ni mo mã ṣe fun ọ. O yẹ ki gbogbo rẹ̀ ti pari ki a to ṣe ipade miran.

Iyalẹnu ni o jẹ lati ri i pe ijoye pataki kan ni eleyi ṣugbọn nigbati o duro niwaju Alaga yi, enia mọ pe ijoye ju ijoye lọ, bayi ni ọrọ ti nwọn jọ sọ lọ:

*Alaga :* Ṣe iwọ ni ijoye ti o wa si ipade lati apa oke?

*Ijoye :* Bẽni.

*Alaga :* Ó di ẽmẹta ti o wa si ipade.

*Ijoye :* Ẽmẹrin ni, oluwa mi.

*Alaga :* Njẹ ipade ti ó kọja kọ l'o bẽre ẹgbãji pọnun?

*Ijoye :* Bẽni, oluwa mi, gbogbo owo nã si ti tan patapata.

*Alaga :* O tun nfẹ diẹ si i.

*Ijoye :* Õtọ ni.

*Alaga :* Ẽlo ni o fẹ si i?

*Ijoye :* Ẹgbãfa pọnun to.

*Alaga :* Ó ó ba a ninu iyara rẹ.

*Ijoye :* A dupẹ, oluwa mi, o tun ku kini kan.

*Alaga :* Kini?

*Ijoye :* Mo nfẹ ade ọba mẹfa, ki meji kun fun ọpọlọpọ diamọndi, ki meji jẹ kiki gõlu, ki meji si jẹ ti fadaka.

*Alaga :* Tabi ọba Alade ni ọ?

*Ijoye:* Ò tì, mo fẹ lọ fi wọn wa, oju awọn ọba nla nla gbogbo mọra ni.

*Alaga :* Eleyini ko ṣoro rara, awọn ọmọ mi yio gbe wọn wa fun ọ ni ile.

*Ijoye :* Mo dupẹ.

*Alaga :* Igbawo ni ki a mã reti rẹ?

*Ijoye :* Ṣe l'ọrun?

*Alaga :* Hãn, Ọrun Apadi.

*Ijoye :* Ọdun mẹfa pere l'o ku, mọkanlã ni iba jẹ, ṣugbọn mo ti yọ marun ti ẹ nyọ kuro. O tilẹ nwù mi ki nmọ bi ibẹ ti ri.

*Alaga :* Ṣugbọn ibẹ ko ni anfani kan, airi ibi lọ ni emi pāpā. ko fi le kuro nibẹ, ẹ̀wọ̀n ti Olodumare fi mi si ni.

"Bayi ni gbogbo wọn sa ṣe ti nwọn nwa si iwaju Eṣu, ọba wọn awọn ẹni buburu aiye wọnni, ti nwọn nṣe ipade wọn ni ọganjọ oru. Igbati Kòtẹ́milọ́rùn wò wọn o ri i pe oriṣiriṣi enia l'o wà nibẹ ati enia dudu ati enia funfun ati eyiti ko dudu ti ko funfun ti nwọn pupa bi ọgẹdẹ ati awọn ti nwọn ga fiofio ati awọn ti nwọn kuru bi kukute, ati awọn ti nwọn sanra ti nwọn tun ga, ti nwọn sigbọnlẹ ti nwọn jẹ òmìrán ati awọn ti nwọn kuru ti nwọn jẹ ràrá, gbogbo wọn l'o pe sibẹ bamubamu, awọn ti nwọn dudu ni nwọn pọ ju nibẹ nitori nwọn ko ti iṣe ipade gbogbo agbaiye nibiti awọn ọmọ enia l'origun mẹrẹrin aiye yio pejọ si gẹgẹ bi aṣoju agbegbe wọn."

Igbati o ṣe ni Alaga nā bẽre bi awọn ti o ṣẹṣẹ wa wọ ẹgbẹ ba wà tabi nwọn ko si, awọn ti ó wá to mẹfa ti a ba mu Kòtẹ́milọ́rùn pẹlu wọn. A o fun awọn wọnyi ni orukọ, a o pe ẹni kini ni A, ẹni keji ni B, ati bẽ bẽ lọ.

Igbati nwọn mu A de iwaju Alaga yi bayi ni nwọn ṣe sọrọ si ara wọn.

*Alaga :* Kini orukọ rẹ?
*A :* A, ni orukọ mi.
*Alaga :* Ọdun wo l'a bi ọ?
*A :* Ọdun 1935 ni.
*Alaga :* Tal'o mā mā sin lati oni lọ.
*A :* Ẹnyin ni ng o mā sin.
*Alaga :* Ṣe ki nkọ orukọ rẹ?
*A :* Ẹ ko ọ.
*Alaga :* Awọn nkan alejo awọn agbalagba ti o mu wa da?

Bi o ti ṣe ibẽre yi ni ẹniti o mu A wa ju ọwọ si ibi kan bayi afi igbati awọn ohun ọsin funfun jade, aja funfun, aguntan funfun, ewurẹ funfun, pẹpẹiyẹ funfun, akukọ funfun, ologbo funfun ati ẹiyẹle funfun.

Lẹhinnā, Alaga yi mu nkan kekere rógódó kan jade lati abẹ tabili rẹ o tikararẹ fi i si ọkunrin yi lẹnu o ni ki o gbe e mì, on nā ba gbe e mì.





'Bayi ni gbogbo wọn ṣe ti nwọn nwa siwaju Eṣu, ọba wọn'

Lẹhin eyi o bẽre o ni, "Kil'o fẹ ki nṣe fun ọ?"
A nã dahun o ni, "Mo nfẹ ni owo."
Alaga tun bẽre o ni, "Ṣe ãdọta apo owo to ọ?"
On nã fesi o ni, "O to mi dãdã".

Alaga tun ni ki ó mã lọ si ile yio ba owo nã ninu iyãra rẹ̀. Ọgbẹni A ba lọ joko.

Igbati o kan B, bayi ni ọrọ ti Alaga ati B ṣe lọ.

*Alaga :* Kini orukọ rẹ?
*B :* B ni orukọ mi.
*Alaga :* Tani o ó mã sin lati oni lọ?
*B :* Jesu ni.

Ṣe ni Alaga binu, ti gbogbo awọn ti o wa ni ipade binu pẹlu nwọn bẹrẹsi wi pe má sọ bẽ mọ, má darukọ rẹ̀ mọ ati bẽ bẽ lọ.

Alaga ba tun bẽre : "Mo mọ ẹniti o ti nsin ri, tani o mã mã sin lati oni lọ?"

*B :* Jesu ni.

Were ṣe ni Alaga fa kumọ ti a npe ni ọgọ ẹlẹgbara yọ ti o lẹ B lọ patapata.

Ijangbọn fẹrẹ bẹ silẹ ninu ipade nã, nitori ẹniti o tun tẹle ọkunrin yi tun mu ki Alaga binu, a o pe on ni D. Bayi ni ọrọ ti nwọn jọ sọ si ara wọn lọ.

*Alaga :* Kini orukọ rẹ?
*D :* D ni orukọ mi.
*Alaga :* O mọ ọjọ ibi rẹ?
*D :* Nko mọ ọ.
*Alaga :* Jẹki nwo o fun ọ.

Bi o ti wi bayi o ki ọwọ bọ abẹ tabili rẹ̀ o gbe iwe nla kan jade, igbati o si wo inu rẹ̀ o ni, "Ọjọ kẹtadilogun oṣu July, 1929 ni nwọn bi ọ".

*Alaga :* Kil'o nsin?
*D :* Mọmọdu ni.
*Alaga :* Mo ni kil'o fẹ mã sin?
*D :* Mo gbagbe, Allah ni.
*Alaga :* Mo mọ pe o ti nsin Allah ri, ṣugbọn nisisiyi ti o ti mọ mi yi nkọ, kil'o ó mã sin?





*D :* Obinrin nã duro diẹ o ni 'Allah ni ng o mã sin titi lailai.'

Alaga wa binu pupọ, o ke, o wa bẹrẹsi yọ ahọn bérébéré bi ejo, ehin ẹnu rẹ̀ ta yọ si odė wọ́nganwọ̀ngan, ó tẹ̀ bi gọ̀ǹgọ́ ilu. O ni 'Mo bi ọ o ó mã sin mi lati oni lọ tabi o ko ni sin mi?' Onitọhun tun dahun o ni 'Allah ni ng o mã sin". Eṣu fa ọgọ yọ, o lẹ e jade. Lẹhin eyi, o bẹrẹ ọ̀rọ̀ 'A! A! A! Aiye mi ni yi.

Ẹnyin ti ẹ nṣe yẹ̀yẹ́ mi, o to gẽ.
Ẹnyin ti ẹ nfi iwọsi lọ̀ mi, o to gẽ.
Ẹnyin ti ẹ nwa mi ti ẹ nmu enia wa, o to gẽ.
Mo nilati fi opin si i loni.
Nko ni gba igbakugba mọ.
Allah ti ẹ nke pe yi nã l'o sọ mi di bayi.
Ṣe ẹṣẹ mi ko ju owú ti mo jẹ lọ.
Ṣe mo jowu Olodumare ni.
Ṣe on ni awọn ogun ọrun fi dide,
Ti nwọn ni afi dandan bi mo lọ,
Tí Ọlọrun Ọba kó mi lọwọ soke,
Ti ó ṣe bẽ ti ó sọ mi sinu ọ̀gbun,
Nibiti mo wa di oni oloni.
Ọ̀gbun, ile ẹjọ, ilẹ ija, ile ina, ile ẹ̀wọ̀n.
Ile oró, ile ẹ̀gàn, ile èké, ile ìkà.
Ile ibanujẹ, ile ijangbọn.
Ile ijamba, ile irira.
Ile iwọsi, ile rogbodiyan.
Mo njẹ iya lori iya. Ẹkún lori ẹkún.
Ọ̀sé lori ọ̀sé, ni o jẹ ipin mi ni Ọrun Apadi.
Ki ebi pa ni, ki a jẹ ki a má yo.
Ki ongbẹ gbẹ ni, ki a mu omi odo gbẹ ki ó má tu ni lara.
Ki ile wa ni okunkun biribiri.
Ki õrun pa, pa, pa ki gbogbo ara mõru.
Ki ojo rọ̀ rọ̀ rọ̀ ki gbogbo ara tutu nini.
Iru ipo yi ni ẹniti ẹ ntẹle fi mi si, ẹnyin ọmọ enia.
Ibẹ l'ó fi mi si, emi Ẹlẹgbara.
Emi Eṣu bèlèké, emi Àṣìtánì ti

Ẹ ngbe onjẹ rẹ̀ si orita mẹta. Ẹ-ni-kẹ-ni, mo tun wi, ẹnikẹni, mo tun wi lẹ̀kẹta, ẹnikẹni, ti o ba mu enia wa, ti ko ti gbọ lẹnu oluwarẹ̀ pe on ti kọ awọn ọta mi silẹ, yio jiya ti ko nireti, mo le sọ oluwarẹ̀ di ekute ki ó mã jẹ ẹrún onjẹ kiri. Mo le sọ ọ di ọ̀yà ki ó mã ge eweko jẹ, ki ọdẹ mã le e kiri, bẽni mo si le sọ ọ di ejo oloro ti awọn ọmọ enia yio mã fi ada pa, emi nã, ọba ti o ju ọba lọ, Alaiyeluwa, Eṣu, Ẹlẹgbara, Ọba Ọrun Apãdi.

"Lẹhin eleyi ẹnikẹni ko tun mu Alaga binu mọ. Olukuluku awọn ti ó kù de iwaju rẹ̀ wipe awọn gba a bi oluwa awọn ni.

"Igbati o pari gbogbo nkan wọnyi tan l'o wa bẽre ki olukuluku mu ohun ọsin funfun ti o mu wa. Kòtẹ́milọ́rùn kò mọ pe ẹniti o mu on wa ti ko gbogbo nkan ọsin tì si ibiti olukuluku nfi tiwọn si, nitori ko ri i ki o mu ohunkohun lọwọ ṣugbọn o ti gbe wọn fo wa ki Kòtẹ́milọ́rùn to de ibẹ ni ọganjọ oru ọjọ nã.

"Igbati nwọn ko gbogbo awọn ohun ọsin funfun wọnni jọ, nwọn pọ pupọ gãn. Lẹhin eleyi ni nwọn pin awọn apo kan kãkiri ti nwọn npe ni àpò ẹ̀jẹ̀. Gbogbo ara apo nã kun fun iyẹ. Aṣọ ti nwọn fi ṣe apo nã dabi rọba. Lẹhin eyi ni nwọn tun pin agbari enia kiri, agbárí nã to igbá dãdã.

"Igbati nwọn ṣe iwọnyi tan ni Alaga lu agogo fun onjẹ. Were, gbogbo ipade dakẹ jẽ gbogbo awọn ti nwọn wa bẹrẹsi wo awọn ohun ọsin wọnni. Igbati eleyi ba wo o diẹ a da ẹnu kọ inu àpò ẹ̀jẹ̀, a tu ogunlọgọ ẹjẹ si i, igbati o ba tun ṣe diẹ, tọhun a tú apo rẹ̀ lẹnu a da ẹnu kọ ọ, ọpọlọpọ ẹjẹ a tú jade. Igbati o to iṣẹju mẹ̃dọgbọn, ṣe ni awọn ohun ọsin wọnni bẹrẹsi ṣubululẹ ti ko si ẹran tabi ẹjẹ lara wọn mọ ti gbogbo wọn ku. Nwọn ti fi oju lasan jẹ wọn tan.

"Lẹhin eyi ni Alaga paṣẹ ki olukuluku fi agbari bu ẹjẹ ninu apo rẹ̀ ki o gbe e si ọwọ ọtun ki o fi ọwọ osi le àpò ẹ̀jẹ̀ ki o ṣe ibura. On nka ibura nã awọn yoku ntẹle e. Igbati o ba kan ki a darukọ ara ẹni olukuluku a darukọ ara rẹ̀ eyiti Kòtẹ́milọ́rùn ka ni a o fi ṣe apẽrẹ bayi l'o lọ:

"'Emi, Kòtẹ́milọ́rùn, ọmọ Ijangbọn-ade, ti ngbe ile Inunibini, fi agbari yi, ti iṣe agbari enia, ati ẹjẹ inu rẹ̀ da majẹmu,





loni, ọjọ kejidilogun oṣu keje, ẹ̃dẹgbẹwa ọdun, o le mọkandilọgọta, lẹhin iku oluwa wa, pẹlu, ọba nla yi, ti iṣe olotu Ọrun Apadi, Eṣu, bèlèké, Ẹlẹgbara, Àṣìtánì, baba bilisi, pe, lati oni lọ, mo di tirẹ̀, pe, lati oni lọ, on nã di temi, mo fi ẹmi mi fun u, mo fi ara mi fun u, mo si fi ọkan mi fun u, ki iṣe ni igba igbesi aiye mi nikan, bikoṣe lẹhin iku pẹlu. Igbati mo ba pa oju dẹ, ti mo ki aiye pe o digbõṣe, Angẹli Ọlọrun, ko gbọdọ pade mi, ṣugbọn kàkà bẹ̃, Angẹli Eṣu ni yio wa, lati mu mi lọ, si ọdọ ọrẹ mi yi, ni Ijọba rẹ̀, ni Ọrun Apãdi. Iya ti ọrẹ mi ba njẹ, a o mã jọ jẹ ẹ ni, ẹkún ti o ba nsun, a o mã jọ sun u ni, òṣé ti o ba si npa, a o mã jọ pa a pẹlu. Ṣugbọn, ninu Majẹmu yi, Eṣu ni ipa tirẹ̀ lati sà, o ni iṣẹ tirẹ̀ lati ṣe, ohunkohun ti mo ba fẹ ni ode aiye, ó nilati wa a fun mi. Bi mo nfẹ owo, o nilati ba mi wa owo, bi mo nfẹ ọmọ o nilati wa a fun mi, bi mo si nfẹ ipo, Eṣu ko gbọdọ fi dù mi, ẹniti mo ba fẹ ki ó ku, nilati ku, eyiti mo ba fẹ ki ó ṣaisan, nilati ṣaisan, ẹniti mo fẹ ki jamba ṣe, nilati pade ijamba, ẹniti mo ba si nfẹ fa sẹhin, ko gbọdọ ṣai di ẹni ẹhin. Ẹnyin irunmalẹ inu aiye, ẹ gbọ bi mo ti wi, ẹnyin igba mọlẹ inu aiye, ẹ gbọ bi mo ti wi, ẹnyin oṣo inu aiye, ẹ gbọ bi mo ti wi, ẹnyin ajẹ inu aiye, ẹ gbọ bi mo ti wi, ẹnyin babalawo nla, ẹ gbọ bi mo ti wi, ẹnyin adahunṣe pataki, ẹ gbọ bi mo ti wi, ng o gbe agbari enia yi nisisiyi, ng o gbe e ti ẹnu mi, ng o da a mu giriri.'

"Bayi ni gbogbo wọn ṣe.

"Igbati nwọn mu ẹjẹ inu agbari ti nwọn kọ bu tan, nwọn mu gbogbo ti inu àpò ẹ̀jẹ̀. Igbati nwọn ṣe bayi tan, ṣe ni gbogbo wọn tun fi ọwọ gbá inu ti nwọn nkigbe onjẹ ti nwọn si tun nkigbe nkan mimu. Ìyà ti Ẹlẹda fi jẹ awọn enia buruku wọnni ni pe, bi o ti wu ki nwọn jẹun to, nwọn ko ni yo, bi o si ti wu ti nwọn mu nkan to, ko ni tẹ́ wọn l'ọrun lailai.

"Lẹhin gbogbo ipade yi, Alaga ki gbogbo wọn dãdã. Bi o ti ki wọn tan afi yẹ̀ẹ̀ẹ̀ẹ̀, ti gbogbo ara lọ silẹ. Apa lọ si ọ̀tọ̀ ẹsẹ pinya pẹlu ìdí, ori kuro lara ọrùn. Ọkunrin ti o pe ogede ti Alaga fi wa ba tun bẹrẹ ogede miran, nigbati o pe e diẹ, apa lọ, o tun ṣe, ẹsẹ lọ, ibadi lọ, ọwọ lọ, gẹ̀-ǹgẹ̀ aiya lọ, ọrùn lọ, igbati ori wa lọ ni a ko ri ati tabili ati aga ijoko, ati iwe ori tabili mọ. Ẹnikan ninu gbogbo awọn ti nwọn wà nibẹ

ba ke igbe ni ohun tõro kan bayi ti o dabi ohun ẹiyẹ ṣe ni gbogbo awọn ti nwọn ti wà ni enia yipada ti nwọn di ẹiyẹ. Kòtẹ́milọ́rùn pãpã ri i pe on di ẹiyẹ nitori agbara ti o ti gba lọwọ Eṣu, nwọn ba wale.

"Bayi ni gbogbo awọn ti nwọn lọ si ipade buruku nã pada. Mo fẹ ki ẹ wo onirũru iṣoro ti nwọn ba pade, ki ẹ si wo o ni pataki pe olukuluku awọn ti nwọn lọ ni nwọn mọ bi Ọrun Apãdi ti mã ri, ṣugbọn, ṣibẹ, nwọn pinnu ati gbé ibẹ titi aiye ainipẹkun, nitorikini? Nitori owo. Ko si ẹniti ko bẽre owo, eyiti Kòtẹ́milọ́rùn tilẹ bẽre to sọ ọ di olowo fun iyoku igbesi aiye rẹ̀.

"Ṣugbọn ki nwọn to kuro ni ipade ẹnikan ti o ṣẹṣẹ wọ ẹgbẹ bẽre lọwọ Eṣu idi rẹ̀ ti o fi nyọ ọdun marun marun lara ọjọ aiye wọn kuro.

"Eṣu dahun, Eṣu ni, 'Ẹnikẹni ti o ba njiya a mã wa ki ẹlomiran jiya pẹlu, nitori ero pe ki iṣe on nikan ni on njiya a mã mu ki o le farada iya rẹ̀, awa ti a wa ni Ọrun Apadi njiya pupọ afi ti a ba ntan ara ẹni jẹ, bẽni iya nã ko lopin, titi lailai ni a o ma jẹ ẹ, idi rẹ̀ ni yi ti a fi nwa ẹni mọra. Idi rẹ̀ ti mo fi nfẹ ki ẹ tete wa ni yi.

"Igbati ẹnikan si bẽre igbati iya jijẹ awọn yio bẹrẹ bọya were ti awọn ba de ọrun ni tabi nwọn o ṣe awọn ni alejo diẹ ki iya to bẹrẹ.

"Eṣu ni, 'Ki ẹ to pa oju de gãn laiye ni iya yin yio ti bẹrẹ, awọn ọmọ abẹ mi ni yio tilẹ fi kumọ wa pade yin ti nwọn yio mã fọ yin ni igi. Ẹnyin nikan ni yio ri wọn awọn ti o joko tì yin laiye ko ni ri wọn, ohùn yin nikan ni nwọn o mã gbọ, nitorina, ẹ jẹ iwọn ti ẹ mã jẹ laiye ninu igbadun ki ẹ to bẹrẹ iya yin ni ode ọrun'.

"Igbati gbogbo wọn mã kuro ni ipade, nwọn di ẹiyẹ Kòtẹ́milọ́rùn pẹlu di ẹiyẹ nitori Eṣu ti fi eyini fun u.

Fun ọpọlọpọ ọdun, Kòtẹ́milọ́rùn ko ronu ọjọ iku ju bẽ lọ ṣugbọn igbati ọjọ iku rẹ̀ ku ọdun mẹta, a gbọ pe o nba ọrẹ rẹ̀ kan bayi sọrọ ni ọjọ kan, orukọ ọrẹ rẹ̀ nã ni Òyeorí, o dahun o ni, 'Òyeorí, njẹ iwọ ro pe enia tun le lọ si ibikan lẹhin iku?' Òyeorí ni, 'Ótọ mà ni o, o ko gbọ ti awọn kan ní ọrun meji





l'o wa, Ọrun Afẽfẹ Rere ati Ọrun Apãdi, ki Ọlọrun má jẹki a lọ si Ọrun Apãdi o'. Òyeorí ko mọ pe Kòtẹ́milọ́rùn ti wọ ẹgbẹ Eṣu ati pe, o ti yan Ọrun Apãdi ni ibugbe on lẹhin iku, o da Òyeorí lohun o ni, 'Má da wọn lohun, emi ko ro pe bi enia ba ku ẹmi rẹ̀ ko ku ati pe o tun le lọ sibomiran, bi Eṣu pãpã tilẹ wi bẽ fun mi nko jẹ gbagbọ'.

"O nfẹ ki enia da on ni inu dun, ṣugbọn igbati ọjọ iku rẹ̀ ku wakati mẹta, ṣe o ti mọ̀ pe on mã ku ní akoko yi, o dabi ẹni pe ori nfọ ọ diẹ o si ti mọ pe igbẹhin eyini ni iku, o sọrọ lóhùn arò o ni,

'Eyini ni pe o ku wakati mẹta pere fun mi lode aiye.
Mẹta pere ti mo mã bẹrẹ iyà, ti mo mã bẹrẹ ẹkún, ti mo mã bẹrẹ ọ̀sẹ́. Ti ng o wọ ẹwu ibanujẹ ti nko ni bọ ọ silẹ mọ, ti ng o de fila oró ti nko ni ṣi i l'atari mọ.
Ti ng o wọ ṣokoto ijangbọn ti yio wà ni idi mi lailai.
A! Ẹlẹda mi, Ẹlẹda mi, Ẹlẹda mi, kini ṣe ti o ko le yi mi lọkan pada nigbati mo npèrò ajaga nla yi!
Ẹlẹda mi, Ẹlẹda mi, A! Ẹlẹda mi, iwọ nikan l'ó kù ni olutunu fun mi—Ẹlẹda mi.'

"Igbati o ku iṣẹju marun ti Kòtẹ́milọ́rùn mã fi aiye silẹ, Eṣu de pẹlu awọn Angẹli rẹ̀ lati mu u lọ, on nikan l'ó ri wọn awọn ti o joko ti i ko ri wọn, Igbe nla ni nwọn kọ́ gbọ, 'A! Ẹlẹ́gbára, Ẹlẹ́gbára, Ẹlẹ́gbãra, má fi agbara mu mi. A! ó ha mi l'ẽkan loju! Ninu oju! L'ẹ́yinlójú! A! Ewo ni ti kumọ ni gongo imu? Ha! Eleyi tun fọ́ mi ni kumọ ni ipakọ. Ha! Eṣu, Ọ̀dàra, ìyà yi pọ ju! Ha! Eleyi tun nà mi ni irin ni iwaju! O fẹ fọ mi lori ni? Ẹ tun gbe mi lulẹ, ẹ fà mi l'ẹsẹ, ẹ nwọ́ mi l'ori ẹ̀gún lọ. E! Aiye mi ni yi! Bayi l'o ṣe mi? Owó, owó, owó, owó, a! Owó owó owó owó — wó — wó — — ó — ó'.

"Bayi ni Kòtẹ́milọ́rùn ṣe fi aiye silẹ.

"Ki a tun sọ lẽkan si i, owo nini dara, ṣugbọn ko yẹ ki enia wá owo kọja ibiti o yẹ. Awọn ẹlomiran wà l'ode aiye ti nwọn jẹ ẹrú owo, ko si ohun ti nwọn ko le ṣe lati ri i. Ọpọlọpọ tilẹ ṣe tobẽ ti o jẹ pe á kó owo jọ lasan ni, ati lo o fun anfani ara on pãpã di iṣoro, onjẹ wọn a buru ju ti talaka, aṣọ wọn a pupa

bi ti aparo, ile wọn ko si dara ju búkà lọ, sibẹ owo wọn lọ rẹbẹtẹ ni Banki. Loju emi, bi ẹni pe ẹni bẹ̃ ti gba èpè l'o ri, iru awọn wọnyi pãpã fẹran owo ju ọmọ lọ. Owó ṅiǹi dara, ṣugbọn ẹniti o fi owo dipo Ọlọrun Ọba, ẹṣẹ nla ni eleyiǹi gbà.

"Ibiti ng o sọ loni mọ ni eyi bi ó ba tun di ọla, ki ẹ wa gbọ ọrọ diẹ si i."



# ỌJỌ KẸTA NINU ỊLE MỌGAJI ẸNUDUNJUYỌ

Igbati o di ọjọ kẹta ti gbogbo enia ti nlọ si ile Ẹnúdùnjuy ni Mọgaji ile nã tun bẹrẹ ọrọ bayi.

"Ẹnyin ọmọ Ajedubulẹ, ẹ o ri i pe ni ọjọ kọ̃kan ti ẹ ti nw si ile ỹi pe mo nsọrọ lori iwa kọ̃kan tí ọmọ enia nhu, mo s nfi itan kọ̃kan ṣe apẹ̃rẹ ọrọ ti mo nsọ. Loni, mo fẹ bẹrẹ pẹl alọ́ kan mo si fẹ ki ẹ ja àlọ́ nã, itumọ àlọ́ yi ni yio jẹ ohun t mo mã sọrọ le lori.

"Obinrin kan lọ ni ọjọ kan, ó wá májèlé ti o buru pupọ ti o jẹ pe werewere l'o npa ẹniti o ba fi kan ẹnu, o mu majel yi, ó dà a si orisun omi kan, ẹni kini mu ninù omi nã, ó kú ekeji mu, ó kú, gbogbo enia wa mọ pe májèlé wà ninu omi y nitori eyi nwọn ko pọn omi nibẹ mọ. Ìwà wo l'a le fi w majele yi?"

"Igbati o sọ bayi, ko si ẹniti o le ja a, igbati o pẹ, ti ẹnikẹn ko mọ majele nã o wi fun wọn o ni, aimore ni. Ẹniti a ṣe lõrẽ ti ko mọ ọ ti bẹ́ igi di ọna fun ẹlomiran, majele ni ẹn bẹ̃ lãrin awọn ọmọ enia ko si ẹniti yio fẹ mã ṣõre fun u mọ, bẹ̃ni ẹniti o ba ba a pade lẹ̃kan ko tun ni fẹ ṣe õre fun ọmọ ẹlomiran. Alaimõre a mã ba inu enia jẹ, enia buruku ni, ẹn ibi ni, iru awọn enia bẹ̃ fi àwọ̀ enia bo ara ṣa ni, ṣugbọn agbar ẹranko ni nwọn gbe le ori, awọn ni iyọ ti o ti di obu ninu aiye, akẽkẽ lãrin ọmọ enia, paramọlẹ ninu koriko, nwọn ko ba enia jọ, nwọn ki iṣe ọmọluwabi, nwọn jẹ ẹ̀gún ọ̀gàn on ọ̀ṣùṣú, pẹlu atẹlẹsẹ, nwọn a mã ri ere iṣẹ wọn laiye, bi nwọn ko si tilẹ r i laiye, dandan ni ki nwọn jẹbi niwaju Agbẹjọro Ọlọrun n ode ọrun.

"Ẹ wo itan yi ti yio fi ohun ti mo wi han yin kedere. Ọkũnrin kan wà ti o ni iyawo meji, ọkọkan bimọ kọkan, ọmọ ti olukuluku si jẹ ọkunrin. Ọkunrin yi sọ orukọ ekini ni Òbédiní ó sọ t ekeji ni Òbédèjì, on ngbe ilu Ọgbọn-aiye.

"Awọn ọmọ mejeji yi dagba nwọn si nṣiṣẹ òwò. Ko pẹ lẹhin ti nwọn di ọkunrin ni baba wọn ku ti o fi apo owo marun

marun fun ẹnikọkan. Òbédiní joko si ilu wọn o nfi owo yi ṣòwò, òwò nã dara, owó si nwọle fun u tobẽ ti o jẹ pe ãrin oṣu mẹfa l'o fẹ iyawo meji si ile ṣugbọn lẹhin ti o fẹ awọn meji yi, ko tun fẹ iyawo si i mọ. Odidi ọdun mẹfa ni Òbédiní fi ju Òbédèjì, nitorina, igbati on fẹ iyawo wọnyi, aburo rẹ ko tilẹ ti ironu obinrin rara. Orukọ iyawo tí Òbédiní kọ́ fẹ ni Àmì bi o si tilẹ jẹ pe ko bimọ fun ọpọlọpọ ọdun sibẹ ọkọ rẹ fẹran rẹ pupọ nitori ki isaba ri obinrin nã pẹlu ọkunrin k'ọkunrin nitori eyi o ka a si olododo. Iyawo keji bimọ dãdã, o tilẹ ti bi to mẹfa ti iyawo kini ko bi, ti ko tilẹ ṣeṣi loyun. Igbati o ṣe ṣa, obinrin ti ko bimọ yi bẹrẹsi din ifẹ rẹ ku si bãle rẹ, ṣugbọn onitọhun ko mọ nkankan."

A ti mã ba ọkọ rẹ ta nkan ni ilu wọn ṣugbọn nigbati o ṣe o wi fun ọkọ pe on fẹ mã gbe ọja lọ si idalẹ ta, ko dede, o ti ri ọkunrin kan ti ó nfẹ ni ikọkọ, ilu ibiti o si fẹ mã gbe ọja lọ ni ilu ọkunrin nã. Òbédiní ko mọ nkankan, iwa ti o si nhu si obinrin yi dara tobẽ ti o ṣoro fun obinrin nã lati ja rara, Òbédiní ba a de ibi ki ó mã gun iyan fun u jẹ, ki ó mã lọ ata ọbẹ ki o si mã pọn omi iwẹ fun u.

"Sibẹsibẹ obinrin yi ko ni ifẹ rẹ tobẽ mọ. Igbati o ba tilẹ lọ ni aṣiri lọ ri ọkunrin ti o nfẹ yi, bibu ti ọkunrin nã nbu Òbédiní ṣiṣãta ti o nṣãta rẹ, ati ẹgàn rẹ ti o npa to mu ki ọkọ tẹ́ loju aya.

"Lasan ni obinrin yi ko fẹran Òbédiní pupọ mọ, ṣugbọn ko fẹ iku rẹ. Bi ko si ti fẹ iku rẹ yĩ, o ti sọ aṣiri ile wọn tobẽ fun ọkunrin ti nba kiri yi ti o fi jẹ pe ọna ati pa Òbédiní ko ṣoro fun ọkunrin nã bi ó ba fẹ. Oko ni Òbédiní mã nsun ni ọjọ Satide gbogbo nitori onigbagbọ ni wọn ni ile isin ni oko wọn on si jẹ ọkan ninu awọn pataki ti nwọn so ile isin nã ró.

"Ọrọ ti ọkunrin ti o nfẹ Àmì ni ikọkọ yi sọ nigbati nwọn pade ni igbakan yio fihan iru enia ti ọkunrin nã jẹ. Igbati Àmì wa ki i ti o npada, o ni, 'Àmì, o wu mi pupọ, ṣe iwọ nã ri i pe mo fẹran rẹ, ọkọ réderède ti o ngbe kiri yi, ko yẹ ọ, iwọ pãpã ko kuku fẹran rẹ to mi, a nilati wa bi a o ti ṣe ti ọkọ rẹ yi si.' Àmì nã dahun o ni, 'Lõtọ, mo duro ti i ki ó mã fun mi ni onjẹ ni, mo fẹran rẹ ju u lọ, ṣugbọn ko si nkan ti a le ṣe, a ko kuku le pa a.' On tun dahun, o ni, 'A le pa a mọ̀nà





Kil'a o le pa?' Àmì fesi wayi pe on ko fẹ ki Òbédiní ku, nitori o ti ntọju on ti pẹ.

"Ṣugbọn orukọ oko Obedini ni Onígbàǹja, nwọn sọ oko yi ni iru orukọ bẹ̃ nitori obi gbàǹja ti o pọ nibẹ.

"O ṣe ni owurọ ọjọ kan, ni nkan bi agogo mẹwa, Òbédiní wa lati ta nkan ni ilu ti ọkunrin ti nfẹ Àmì yi ti a npe ni Ìbàjẹ́ọ̀dẽ wà. O rin lọ ni oju ọna oko kan l'o ba yà si inu igbẹ lati ṣe igbọnsẹ. Ibiti o wa yi l'o ti ri ọkunrin kan pẹlu awọn ọmọkunrin bi mẹfa ti nwọn duro si oju ọna ti nwọn nsọrọ. Ọkunrin ti o wa nibẹ bẹrẹsi ran wọn ni iṣẹ bayi, o ni, 'Bi ẹ ba ti de ilu nã, ki ẹ bẽre ọna oko Onígbàǹja. Igbati ẹ ba de Onígbàǹja ki ẹ bẽre abà Òbédiní. Bi ẹ ba ti ri i ki ẹ bá ibomiran lọ ki ẹ mã ṣire titi ilẹ yio fi ṣu. Nigbati o ba di ãrin ọganjọ ní nkan bi agogo mejila, ki ẹ lọ, ẹ o ri i pe gbogbo ilẹkun ati ferese ti ó wà ni abà nã ni enia le tì ninu tì lode, ki ẹ ti gbogbo wọn lode lẹhin eyi, ki ẹ fi ina si abà koriko nã ki ẹ sun u ki o jona gúrágúrá, Òbédiní yi, ni ọkọ obinrin ti mo nfẹ nã, mo si fẹ lati fẹ oju rẹ kù. Ẹ tun gbọ o, ki ẹ má gbagbe, abà, abà, abà Òbédiní, Òbédiní, Òbédiní. Oko Onígbàǹja, ẹ maṣe gbagbe orukọ nã o, Onígbàǹja, bi ẹ ba fẹ gbagbe ki ẹ ranti obi gọ́rọ̀, orukọ gọ́rọ̀ keji ni gbanja. Òbédiní nã, ọkọ obinrin kan ti a npe ni Àmì ni. Ẹ maṣe gbagbe o. Ilu nã ni a si npe ni Ìbàjẹ́ọ̀de.'

"Bayi ni ọkunrin na wi, awọn ọmọkunrin wọnyi si gbọ, nwọn kọ orukọ gbogbo silẹ pẹlu.

"Ṣugbọn gbogbo ọrọ yi, ọwọ aburo Òbédiní ti njẹ Òbédèjì ni nwọn sọ ọ le, ó jẹ ọjọ Satide ti Òbédiní yio lọ si oko bi ẹnikẹni ko ba si de ilu nã ki agogo meji ọsan to lu ko le ba Òbédiní ni ile mọ.

"Ọpọlọpọ enia ni Òbédèjí ti dá ìgbà fun pe ki nwọn wa ba on nipa ọjà ti on nta ni agogo kan si mẹta, bẽni mọto si ilu Òbédiní kò wọpọ. Ohun ti Òbédèjí wa ṣe ni pe o hãya alùpùpù kan o fi ran ẹnikan si ẹ̀gbọn rẹ ki o jiṣẹ bayi pe ẹgbọn on ko gbọdọ lọ si oko titi on o fi de ni oru ọjọ nã.

"Ẹniti o ran pade Òbédiní ni ẹnu ọna ti o mura ti o nlọ si oko, ni igbati nwọn si jiṣẹ, o nilati ran enia ki o lọ si Onígbàǹja ki ó ba wi fun awọn enia ijọ pe on ko le wa lọjọ nã. Ibiti o

ti nronu ẹniti on iba ran ni aburo Àmì, ọmọ iya rẹ̀ ti o wa si ọdọ wọn, wipe on o kuku lọ ki on sun ni oko mọju. Ṣe ni obinrin yi wa gbe õgun kan fun Àmì ẹgbọn rẹ̀ ti o jẹ pe ko si Obinrin ti o le lo o ti kò ni loyun werewere. Obinrin yi lọ si Onígbàǹja.

"Oru patapata ni Òbédèjí to de, igbati o si ro nkan ti on bá wa fun ẹgbọn rẹ̀, onitọhun ko gbagbọ rara o sẹ de ilẹ koko o ro pe Àmì ko ni ọkunrin miran bi ko ṣe on. Igbati ilẹ ọjọ keji mọ ni ẹnikan ti oko lọhun de ti o jiṣẹ pe nwọn ti jo aba Òbédiní gúrágúrá ati pe aburo iyawo rẹ̀ ti jona pẹlu.

"Igbati Àmí de ti ọkọ rẹ̀ bẽre, o sẹ o tilẹ tun ṣẹ epe le ara rẹ̀ lori bi on ba ní ẹlomiran lẹhin bãle on. O ni bi on ba nlọ si ọdọ ẹlomiran ju bale on, ṣe ni ki Kiniun pa on jẹ, ọkọ rẹ̀ ṣẹ́ epe nã danu. Ṣugbọn ẹkún aburo rẹ̀ ti o sun pọ pupọ, o jẹ ẹniti o fẹran pupọ, ati pẹlu, owo ti o fi ṣe õgun ti o jona pẹlu aburo rẹ̀ ninu abà ko kere, o si mọ pe aburo on nilati gbe õgun nã lọ si oko.

Àmì ko wa si Ibajẹode fun ọjọ pipẹ nitori ọrọ ti ọkọ rẹ̀ sọ si i, ṣugbọn ọkunrin ti o nwa lọ ko ye ranṣẹ si i ni aṣīri, on pẹlu ko si ye ranṣẹ pada. Lọjọ kan ọkunrin yi wa kọ iwe ifẹ si Àmì ti o jinlẹ gidigidi bayi ni iwe nã lọ:

"'Àmì mi tõtọ, Àmì mi pataki,

Yara mu abẹ́rẹ́ wa, ki ó ran ọkàn mi ti ifẹ ti faya. Ifẹ rẹ nru bò mi lojojùmọ bi omi okun, ó ti bori ẹmi mi, ó gbe ọkan mi mì patapata. Láì si pe o wa ri mi, o nfẹ iku mi, láì si pe mo ri ọ, o nfẹ sọ mi di aṣiwere, láì si pe o pade mi nibikan, o nfẹ wọ̀ mi ni ẹ̀wù ibanujẹ patapata, Mo wo àṣẹ̀ṣẹ̀yọ õrun owurọ, kò dara to ọ, mo wo àtiwọ̀ õrun, ko le duro nibiti iwọ wà ; mo wo gbogbo ìyẹ́ ẹiyẹ ọ̀kín ko si eyiti o de ibiti iwọ de nipa ẹwà ara, mo wo gbogbo itanna eweko, ko si ẹgbẹ rẹ ninu wọn, bẽni ati iyẹ lekeleke, ati agbado àṣẹ̀ṣẹ̀yọ, ati oju ọjọ ọsangangan ko si eyiti o funfun to ehin ẹnu rẹ. Nisisiyi, nisisiyi, nisisiyi, mo wi fun ọ láì ri ọ ni ọjọ marun oni, maṣe l'ero ati ri mi mọ ng o pa ara mi nitori rẹ.

Emi ni tirẹ Lailai,

Onítbàjẹ́-Ọkunrin.





"Bayi ni iwe ti Àmí ri gba ti ó kà ti ọkọ ko gbọdọ rí.

"Obinrin yi wa bẹrẹsi wa ọna ati lọ pade Oníbàjẹ́-Ọkunrin, o wa a titi ko rí, igbati o ṣe, o wi fun ọkọ rẹ̀ pe ẹnikan jẹ on l'owo ni Ìbàjẹ́-Òde, on si fẹ lọ gba owo nã, ọkọ rẽ na, ti ko fẹ ki ó lọ, wá irọ kan pa pe on nreti alejo kan ti o jẹ pe yio ba on tọju. Obinrin nã ko sa le lọ.

"A ko gbọ pe Oníbàjẹ́-Ọkunrin ku, a ko gbọ pe ó ṣiwere gẹgẹ bi ó ti sọ, ṣugbọn ẹni buruku pọ̀ lode aiye, ọkunrin nã tun wa ọna miran ati mu Òbédiní. Iṣẹ mọ́tò wíwà ni ọkunrin na nṣe dẹ́rẹ́bà ọkọ ni.

"O wa di ọjọ kan on nikan gbe ọkọ nla ó lọ si ọna oko kan, o ri ọkunrin kan loju ọna o fi ọkọ kọlu onitọhun o pa a ku finrínfinrín.

"Eleyi ṣẹlẹ ni nkan bi agogo mẹfa alẹ ẹnikẹni ko ri i titi o fi rọra gbe oku ọkunrin nã jù sinu ọkọ̀ ti o ti gbogbo ferese ọkọ̀ patapata ti o kọ ori si ọna ilu ti a npe ni Ọgbọ́n-aiye yi nibiti Àmì ati Òbédiní ọkọ rẹ̀ ngbe. O de Ọgbọ́n-aiye ni nkan bi agogo mẹsan alẹ o gbe ọkọ rẹ̀ si ibikan o ṣire lọ.

"Igbati o di agogo kan oru gãn l'ó gbe oku o dí ẹhinkunle Òbédiní, igbati o de ibẹ o rọra gbe oku yi sibẹ o ba ti ara rẹ̀ lọ.

"Nigbati ilẹ mọ ti gbogbo enia ri oku lẹhin ile Òbédiní ariwo ta, gbogbo enia ti bẹrẹsi ke, nwọn lọ si ọdọ ọba, awọn ọta Òbédiní ti lọ pe awọn ọlọpa. Ibiti nkan nã si wa ṣe si, Òbédèjì lọ si idalẹ ni akoko nã. Ki a má sa ba ọrọ lọ bi ilẹ bi ẹni awọn ọlọpa fi ẹsun kan Òbédiní pe o pa enia, nwọn fi i si itimọle titi nwọn o fi da ẹjọ́ rẹ̀.

"Igbati onisẹ kan Òbédèjì lara pe nwọn ti mu ẹgbọn rẹ̀, bi aiye l'o wà bi ọrun ni, o ṣoro lati sọ.

"Nigbati Òbédèjì nbọ, o gbe apo owo mẹ̃dọgbọn lọwọ lati fi ṣe ẹjọ nã, ṣugbọn bi o ti de ti o ti gbọ pe awọn ọlọpa ko gba iduro l'o ti ki ẹsẹ si i o nya ile kiri o nṣe alaye bi o ti da on loju pe ẹgbọn on ko pa ẹnikẹni, o de ile Sájì (Sergeant) ati ti Kọ́bùrù (Corporal) o ṣe alaye pupọ o wa lọ gba Agbẹjọ́rò fun ẹgbọn rẹ̀. Agbẹjọ́rò ní afi dandan bi on gba apo marun fun ẹjọ nã nitori ẹjọ lile ni, gbogbo eleyi ni Òbédèjì san. Ni igbẹhin o fi apo marun duro fun ẹgbọn rẹ̀.

"Titi di isisiyi, ẹnikẹni ko ti imọ nkan ti o pa ẹniti o ku, ṣugbọn nkan ti Agbẹjọ́rò kọkọ sọ ninu ile ẹjọ ni pe on fẹ ki Dokita lọ yẹ oku nã wò ki o ṣe alaye nkan ti on ro pe o pa a.

"Dokita Ijọba gãn l'o lọ yẹ oku nã wo, igbati o là á o ni, on ro pe mọto ni o pa a ati pe ko iti iju ọjọ mẹrin ti oku nã ku.

"Awọn ọlọpa ba da ọlọpa-inu jù si ode. Nwọn wa gbogbo ilu, nwọn ko ri apẽrẹ, nwọn wa tun bẹrẹsi wa gbogbo agbegbe. Nwọn ṣe titi nwọn ko ri oye.

"Ṣugbọn ko si ẹniti o fura pe Oníbàjẹ́-Ọkunrin ti o nle Àmì kiri l'o le dan iru nkan bẽ wo. O wa ṣe ni ọjọ kan, Òbédiní wà ni ile, Àmí lọ si ode ni ẹnikan dede mu iwe kan wa si ile, Àmì ni nwọn kọ iwẹ nã si ṣugbọn orukọ ti nwọn kọ sẹhin rẹ ni Iyawo Òbédiní (Mrs. Òbédiní) ni iwọn igbati eleyi si ti jọ Ọgbẹni Obedini (Mr. Obedini) Obedini ṣèṣì ja a. Kil'o ma ri ?

"'Àmì temi pataki,

'Mo ro pe nwọn o ti pa ọkọ rẹ nisisiyi fun oku ti nwọn ri ni ẹhinkunle rẹ. Emi ni emi mã fẹ ọ, Àmì, o kò mọ nkan ti mbẹ ! Ng o ri i pe ọkọ rẹ yi ku patapata, l'ọjọ ti a ba si tun pade ng o jẹki o mọ bi oku ti ṣe rin de ẹhinkunle yin. Masẹ jẹki ẹnikẹni ri iwe yi o.

Emi ni tirẹ titi lailai,
Oníbàjẹ́-Ọkunrin.

"Ara Òbédiní gbọn, ko si ṣe meji, aburo rẹ Òbédèjì, l'o fi iwe fun awọn mejeji ba mura o di agọ ọlọpa. Igbati nwọn fi iwe fun awọn ọlọpa nwọn yan awọn Ọlọpa-inu ki nwọn lọ si ilu ti Oníbàjẹ́-Ọkunrin ngbe. Lilọ ti nwọn nlọ, ile ọkunrin nã ni nwọn kọ ori si, inu wọn si dun nigbati nwọn ri mọto kan ti o duro niwaju ile nã ti nwọn wadi ti nwọn gbọ pe ti ọkunrin nã ni. Nwọn tun wadi iṣẹ rẹ nwọn gbọ pe iṣẹ mọto wíwà ni. Nwọn ba bẹrẹsi wa abẹ mọto bọya nwọn le ri àmì ti yio fihan pe ọkunrin yi l'o pa ẹniti nwọn gbe wa ile Òbédiní. Lõtọ nã, bi o tilẹ jẹ pe o to ọjọ mẹrin dãdã ti kini yi ti ṣẹlẹ̀, ẹjẹ wa ni ara irin abẹ mọto, dẹrẹba pãpã ko ri i tẹlẹ.

"Ki a má fa ọrọ gun lọ bi ilẹ bi ẹni, ibẹ ni nwọn ti mu u ti nwọn fi pa-wọ́pẹ́ si i lọwọ. Igbati ọran di ọran kõtu o tun





mu inawo lọwọ. Asẹhinwa asẹhinbọ nwọn da ẹjọ iku fun Onibajẹ-Ọkunrin, ṣe ni nwọn yẹ igi mọ ọ.

"Igbati ihin pe nwọn ti pa ọrẹ Àmí de ba a, ko jẹun titi ilẹ ọjọ nã fi ṣu, ṣugbọn ko ṣe oju bi ẹni pe on nkãnu ẹnikẹni rara.

"O pẹ lẹhin eyi ni Àmí tun lọ si Ìbàjẹ́òde. Igbati o mã kuro ni ile, ilẹ ti nṣu, ọkọ rẹ si wi fun u ki ó má lọ mọ, ati pãpã pe ẹranko buburu pọ ni ọna ibẹ Àmì kò gbọ o lọ dandan.

"Ọjọ kẹta l'o wipe on o pada. Igbati o di ọjọ kẹta ko de, ọjọ kẹrin, ẹnikẹni ko tun ri i, igbati o di ọjọ karun ni ọkọ rẹ ba ki ẹsẹ si ọna ti o wa a lọ. Loju ọna ni nwọn ti wi fun u pe kiniun pa obinrin kan jẹ ni ẹba odo kan lalẹ ọjọ ti Àmi kuro ni ile. Awọn ẹniti ngbe eti ibiti Kiniun ti ṣe ijamba yi mu aṣọ obinrin nã, nwọn ko o pamọ, igbati Òbédiní de ibẹ ti o gbọ ọrọ yi, ara fun u, igbati nwọn si ko aṣọ ẹni nã sode o di ti Àmì, ati gele ati iró ati iborun, gbogbo iwọnyi kun fun ẹjẹ bálabàla. Ibanujẹ nla l'o jẹ fun Òbédiní. Eyiti o tilẹ wa tun buru ni pe igbati Òbédiní sọkun oku rẹ, ẹniti o ba a sọkun ko ju kekere ni ibẹ. Igbati o de ile o nke he ! he ! Dipo ki nwọn rẹ ẹ, ẹrin ni ọpọlọpọ nrin nwọn ni Àmì l'o bura pe ki kiniun pa on jẹ ti kiniun pa a jẹ. Bi ara eke ti o bu pe ki kiniun pa on ni kiniun ṣe pa a, bi kiniun iba si pa a, yala o bura tabi ko bura, eleyini ti oju su mi. Nkan ti o sa da gbogbo wa loju ni pe Àmí bura ki kiniun pa on, kiniun si pa Àmì, ki Ọlọrun maṣe jẹki iru eleyi jẹ ipin wa.

"Aigbe ile ju bẽ lọ ko jẹki Òbédèjì tete ni obinrin, ṣugbọn itan bi o ti ṣe ni obinrin yẹ ni sisọ.

"Fun odidi ọdun meje ko mọ bi arẹmọbinrin ọba ilu wọn ti orukọ rẹ njẹ Àrà-ọ̀tọ̀ ti ri. Ọjọ ti o si kọ fi oju kan obinrin nã ni ọkan rẹ kò ti balẹ mọ. Igbati o pẹ ko tilẹ le jẹun ju bẽ lọ mọ, bi o ba ti ji a lọ si ibi gbàgede ti o yi ile ọba ka a mã rin kiri. Igbati Ọlọrun si mã ran a lọwọ, o to nkan mejilã leralera ti o ṣelẹ ti ọmọbinrin yi nilati jade. O ṣe Alaga ipade tọ mẹjọ ọba si ran a ki o lọ ṣe Aṣoju on to igba mẹrin. Igba wọnyi ko si eyiti Òbédèjì ko lọ.

"Ọmọbinrin nã pãpã ti nṣe akiyesi eyi lati igba kẹta. Igbati o di ọjọ kan ti Òbédèjí ati awọn bi mẹta ninu ọrẹ rẹ

joko ni ọmọbinrin kan dede wa lati ãfin ti o jiṣẹ bayi fun u pe arẹmọbinrin ọba ni on fẹ ri i.

"Aiya gbogbo awọn ti o joko nibẹ l'o ja pe ki ó mã ba ṣe pe Òbédèjí ṣẹ ẹṣẹ kan. O mura, o lọ.

"Igbati o de ọhun nwọn mu u lati ile nla de ile nla, igbati o ṣe ṣa nwọn mu u de õdẹ nla gbalasa kan, ibẹ ni nwọn ni ki o joko si ki o mã reti ọmọ ọba.

"O pẹ diẹ ki ọmọbinrin nã to jade si i. Igbati o si mã jade ṣe ni gbogbo ara rẹ nbù yẹ̀rì lọwọ nkan ọṣọ́. Bi o ti wọle joko tan ni o wi fun awọn ọmọbinrin ti nwọn tẹle e wa ki nwọn mã lọ.

"Igbati nwọn lọ tan l'o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni. 'Dajudaju, ko le ṣai ya yin lẹnu lati ri onişẹ mi, ẹnikan ti ki ifi nkan pamọ fun mi l'o wi fun mi pe on gbọ ọrọ mi lẹnu yin, ẹ bẹrẹsi bu mi, ẹ npẹgan mi, ẹ nṣãta mi ni mo ba ni ki nbẽre nkan ti mo ṣe.'

"Igbati o wi bayi, Òbédèjí fẹrẹ daku o ni, 'Ká-ká, ká, ká, kábiyesi, Ta, ta, ta, ta, ta, l'ẹni nã ti, ti, ti, ti o sọ bẹ̃, ti o, o, o, o, o, purọ mọ mi bẹ?' Àrà-ọtọ́ rẹrin musẹ, o ju ọwọ si i o ni, 'Joko na, kil'o ha nle mi kiri si? Mo ti nkiyesi ọ, ko si ibiti mo nlọ ti nko nri ọ'. Òbédèjí wa dahun o ni, 'Kabiyesi, bi o ba jẹ pe ẹnikan ko sọ fun yin ẹ kàn rò bẹ̃ ni, ki iṣe pe mo mbu yin. Ẹ jọwọ, ẹ dariji mi, Kabiyesi, ọrọ ẹnu yin mã nwu mi gbọ ni'. Ọmọ ọba ba tun dahun o ni, 'Eyini ni pe mo npurọ?' Ṣugbọn o wi i pẹlu ẹrin ni. On nã tun dahun o ni, 'Rara o, Kabiyesi, rara'. On na tun wa dahun, o ni, 'Mo ṣebi ẹ ni a npurọ ni. Ẹ ko wa mã lọ ki iyawo yin má ba binu?' Òbédèjí nã wa nle sọrọ diẹ o ni 'Iyawo? Nibo ni ki nti kò ó?' On nã ba tun dahun o ni, 'Ẹ ye mã tan 'ra yin jẹ, a kuku ni ki á ba yin kẹ iyawo yin ni'. Bayi ni ọmọ ọba nã ba Òbédèjì sọrọ ti o ba a ṣe ẹ̀fẹ̀ dãdã. Igbati o ṣe, ọba ti o ti lọ si ode pada. Bi kàkà-kí ti dun ni ọmọ ọba nã wi fun Òbédèjì ki o wa mã lọ. Ki o to di pe o jade ṣa o bẽre ọjọ ti yio ri aye wa tun ba on ni ãfin, onitọhun nã da ọjọ mẹfa fun u.

"Òbédèjì ko mọ ohun ti on wa le ro. O ha le jẹ pe ọmọ ọba nã le fẹ on ni bi tabi bawo? O ronu titi ko ja a. Igbati o di ọjọ kẹta ṣe l'o dede ri ọmọ ọba nã ti o kọja lẹhin ile rẹ Òbédèjí





ri i pe ọmọbinrin kanṣoṣo l'o wa lẹhin rẹ. Òbédèjì ki i, ko dahun. Igbati o tun di ọjọ keji ti Òbédèjì kọja ni ibi gbàgede ile ọba, ti o ri ọmọbinrin nã ti o duro pẹlu awọn enia kan ni oju gbangba. O ki i Kabiyesi, ko tilẹ fesi rara o nba ọrọ ti o nsọ lọ ní tirẹ̀ ni.

"Ọjọ kẹta lẹhin eyi ni ọjọ ti Òbédèjì ti dá fun ọmọbinrin nã pẹ on nbọ ni ãfin. O de ọhun ki o to ranti pe on ko bẽre bi on o ti ṣe le ri i lọjọ nã. Igbati ó kọ́ wa, ọmọbinrin ti ọmọ ọba ran si i ni o ṣe ọna ti o fi wọ ãfin. Ko pẹ pupọ ti o de ẹnu ọna ãfin ni ti eleyi ti ojo fi bẹrẹsi rọ̀, inu búkà kan, lẹba ãfin l'o sa si, búkà nã si njò ṣe ni gbogbo aṣọ rẹ rẹ jìnnì-jinni.

"Ni owurọ ọjọ keji ní nkan bi agogo mẹjọ ni iranṣẹ tun ti de lati ãfin pe ọmọ ọba nã nfẹ ri Òbédèjì ni oju alẹ ní nkan bi agogo mẹfa àbọ̀. Igbati onişẹ yi jẹ, Òbédèjì bẽre bi on o ti ṣe le wọ ãfin, ọmọ ti o wa ní on o duro de e si ẹnu ọna ati pe ọmọ ọba binu pupọ pe ko wa ni ọjọ ti o ṣeleri, bẽni o wa, ko to wọle ni, o duro bi ẹni pe onişẹ o jade lati ãfin ṣugbọn ko ri ẹnikẹni.

"Ni agogo mẹfa-abọ ọjọ keji, o ti de ãfin, were ni onişẹ mu u wọ ãfin lọ. Igbati o de ọhun ko ri ẹ̀rín lẹnu ọmọbinrin yi, ṣe l'ó fa oju ro ti o nbinu pe o da on duro titi lọjọ ti o wipe on nbọ ti ko wa, ni Òbédèjí ba bẹrẹsi ṣe alaye pe on wa, ojo tilẹ pa on ṣugbọn on ko le wọ ile ni. Ọmọ ọba ba bu ṣẹrin o ti mọ pe o wa, nitori on pãpã ti ranti pe on ko juwe ati wọle fun u, o halẹ bẹ̃ mọ ọ ni.

"Nwọn jọ ṣire pupọ lakoko yi Òbédèjí si ti wa bẹrẹsi ro pe o ní nkan ti Ọmọbinrin nã nwa lara on lọna kọna ṣa, ki iṣe pe o nwa ọna ibi fun on.

"Igbati o mã jade ni ti eleyi, o sin i bọ si ode gbangba. O si wi fun u pe on nfẹ pe e pẹlu awọn ọrẹ on miran wa si ãfin wa jẹ ase ni ọjọ kan. O sọ ọjọ nã fun u.

"Òbédèjí dara pupọ l'ọmọkunrin, arẹwa gbã ni. O da aṣọ kan ni pataki fun ọjọ ase nã. Aṣọ ti o wọ̀ ko niyelori pupọ tobẹ̃ ṣugbọn bi o ti ṣe wọ ọ ni. Agbádá funfun gbõ l'o wọ̀ pẹlu ṣokoto funfun, alágbàfọ́ lọ nkan si aṣọ nã lara, ṣokoto ṣọ́ọ́rọ́ ti o si wọ si i ba a mu lọpọlọpọ, igbati o wa de fila tóómì

si i wayi, ti o fi agogo gõlu si ọrun ọwọ rẹ osi, ti o mbọ, oju ti o wo o ko wo oko.

"Ni owurọ ọjọ keji ọmọ nã tun ranṣẹ wa pe o ku iḍide ọjọ ti o ṣãju o si tun ranṣẹ pe on nfẹ ri i ni nkan bi agogo marun lọsan ọjọ nã.

"Òbédèjí lọ. Igbati o joko diẹ ti o nmu u yi ãfin ka ti o nfi nkan pupọ han a l'o fi agogo diamọndi kan han a ti o jẹ agogo ti enia nso mọ ọwọ. Ọmọbinrin yi wi fun u o ni agogo ti on o fi fun ọkunrin ti on o fẹ ni eyini. Òbédèjí dahun o ni, 'A jẹ pe eleyini bọ s'aiye'. Nwọn tun jọ nrin lọ nwọn nsọrọ, agogo diamọndi yi wa lọwọ ọmọbinrin.

"Igbati o ṣe ti nwọn de ibikan ti ọpọlọpọ aga nla nla wa bayi ni ọmọ ọba yi di Òbédèjí ni ọwọ mu ti o ni ki o jẹki on wo ọrun ọwọ on bi o ti sanra to. Afi igbati o de agogo yi mọ ọ lọwọ ti o ni on fun u.

"Òbédèjí la ẹnu ko le pa a dẹ o ni, 'Kabiyesi, mo ṣe bi ẹ ni ẹniti ẹ mã fẹ ni ẹ mã fi agogo yi fun. Onitọhun nã dahun o ni "Bẹni".'

"Aiya ọkunrin yi ja, ara rẹ gbọn, kini on ni ti on o fi fẹ ọmọ ọba?

"Ọmọbinrin nã ba bu sẹrin o ni, 'ohun gbogbo ti o wa ni ode aiye ni o ni iyà tirẹ. Awa obinrin ti nwọn bi ninu ile ọla ni iyà tiwa ti a njẹ. Ati pa giri ki ọkunrin kọ ẹnu si wa lati fẹ, iṣoro ni. Wo temi, iwọ ti ó yẹ ki ó kọ ranṣẹ si mi, kọ́ l'ó ranṣẹ si mi, emi ti ko yẹ ki nkọ́ ranṣẹ si ọ l'ó kọ́ ranṣẹ si ọ, ọrọ ti ó yẹ ki o ti ẹnu rẹ jade wa l'o nti ẹnu mi jade, l'o ti ti ẹnu mi jade, ti o si tun nfẹ ti ẹnu mi jade. Òbédèjì, o wù mi jọjọ, iwa rẹ wù mi jọjọ, iduro rẹ wù mi jọjọ, isọrọ rẹ wù mi jọjọ, ile rẹ wù mi, ọna rẹ wù mi, ohunkohun ti iṣe tirẹ si wù mi. Mo wi fun ọ, bi o ti wù mi loni l'o mã wù mi l'ọgọta ọdun loni, l'o mã wù mi ni igba ailera, l'o mã wù mi ni igba wahala, l'o mã wù mi ni igba ipọnju, l'o mã wù mi titi aiye, ó wù mi ki awa mejeji jọ fẹ ara wa lọjọ iwaju, olufẹ mi ọwọn julọ.'

"Bayi ni obinrin nã sọ ati fesi Òbédèjí si jẹ iṣoro gidigidi. Igbati o ṣe ṣa, o sọrọ jade lẹnu o ni, 'Kabiyesi, Kini iru mi jamọ ni ode aiye lati ri oju rere yin, oluwa mi? Ẹ fun mi





ni aye ki nsọ ododo inu mi jade. Ati ọjọ ti mo ti fi oju kan yin ni ọkan mi ti wa ninu idãmu, ati mu aworan'yin kuro ni ori ẹmi mi jẹ iṣoro. Nitorinã, iba ṣe pe mo ni owo to, iba ṣe pe mo l'ẹ́wà to, iba si ṣe pe idile mi nilãri to, eleyi iba dun mọ mi ninu gãn ni, ṣugbọn, ẹ wo o, mo kere ju ẹniti o le gbe ẹrù yin, ẹnyin ti ẹ jẹ ọmọ ọba, eleyi, ni ki ẹ jẹki a jọ ro pẹlu ara wa'

"Àrà-ọ̀tọ̀, ọmọ ọba obinrin yi pari ọrọ nã o ni, 'Mo ti mọ bi o ti jẹ ki nto sọ ohun ti mo sọ, bi ó ba si ṣe ti owo ni, eyini ko to nkan, baba mi ti gbọ, iya mi ti mọ, awọn ibatan mi gbogbo si ti fi ọwọ si ọrọ wa, baba mi ṣeleri ẹgbãrun apo owo fun mi, iya mi ṣe ti ẹgbãji, nwọn ti yanju ile ti a mã gbe, nwọn si ti yanju mọto ti a o jọ mã gùn kiri, nitorinã, sunmọ ihin olufẹ mi, ki nfi ifẹ mi fun ọ'. Bi o ti wi bayi, nwọn dì mọ ara wọn nwọn fi ẹnu ko ara wọn lẹnu. Òbédèjí jiṣẹ ni ile fun awọn enia pataki ile wọn. Ki a má sa ba ọrọ lọ bi ilẹ bi ẹni oṣu keji ni nwọn gbe ara wọn ni iyawo.

"Àrà-ọ̀tọ́ dara pupọ nitori ko ṣe nkan lile ri lati ọjọ ti nwọn ti bi i, ṣugbọn dipo ki igbeyawo Òbédèjì dun mọ Òbédini ninu, o bẹrẹsi jowu ni. Owo ti aburo rẹ ni, ọlá ti aburo rẹ ni, ọlà ti aburo rẹ ti ni ko mu u ni inu dun rara, ibanujẹ l'o ngbe kiri. Bi enia ri i, a ba oju jẹ, bi o pade enia a di ẹnu dudu, bi ko ba ni ja a ma poṣe, o ti gbagbe aburo rẹ ti o yọ ọ lọwọ iku lẽkini, ti o fa a yọ lọwọ rogbodiyan lẽkeji ti o si ná ju apo owo mẹwa fun u.

"Òbédèjì jẹbi tí pupọ ninu awọn enia rere mã njẹ, on ni pe nwọn a mã gbẹkẹle enia ju. Nwọn mã nro pe ko ṣoro fun ẹnikẹni lati huwa rere, nitori eyi, Òbédèjì ko fura si ẹgbọn rẹ rara ko si fi ohunkohun pamọ fun u. Igbati ọ̀n kuku ti gbe ọmọ ọba ni iyawo o ti di olowo.

"Ohun ti ó kọ ṣe ni pe ki o pe ẹgbọn rẹ ki o da a ni okowo. O fi ogún apo owo da a ni okowo, o si fi apo mẹwa fun ọrẹ ẹgbọn rẹ nã, ṣugbọn o ya on ni. On nã l'o tun damọran pe ki awọn jọ lọ si idalẹ lọ ṣowo. Àrà-ọ̀tọ́ ti loyun nigbanã. Awọn mẹta wọnyi sa mura o di idalẹ yi on ra ọja ogún apo, ẹgbọn rẹ nã, ogún àpò, ọrẹ ẹgbọn rẹ, apo mẹwa, nwọn mura nwọn nlọ. Bi nwọn ti nti ilu de ilu ti nwọn nta ọja, ọja ti Òbédèjí ni

gbogbo enia nra bi ẹni pe o tilẹ ṣe õgun awure ti o njẹ loju mejeji ni. Eleyi tubọ mu ki owu jijẹ nã le.

"Igbati o ṣe wayi, awọn mejeji yi pa ero pọ ki awọn pa Òbédèjì patapata. Nkan ti nwọn pinnu ati ṣe ni pe ki awọn sọ ọ si inu okun. Ninu ọkọ Oyinbo nla ni nwọn wa, ẹnikẹni si mọ pe igbamiran ni oke ọkọ ti a npe ni 'deck,' awọn ti nwọn wa lapakan le ja sinu omi ki ẹnikẹni má mọ. Ṣe ni nwọn rọra fi ọgbọn ẹtan mu Òbédèjì lọ si apa ibikan loke ti o jẹ pe awọn mẹta pere l'o ku sibẹ. Bi nwọn ti duro bayi ti Òbédèjì yọju ti o nwo okun bi ọkọ ti nlọ ni nwọn bẹrẹ lẽkan ṣoṣo o di jùà ninu omi, nwọn ju Òbédèjì si okun.

"Nwọn pinnu ati pẹ ni idalẹ nã ki o ba jẹ pe igbati nwọn ba pada si ilu ti nwọn bẽre Òbédèjì, awọn le wipe o ti to oṣu marun ti awọn ti jọ pinya.

"Ṣugbọn Òbédèjì a mã wẹ nitori pe ko si gbe ile pupọ, ẹgbọn rẹ ko mọ bẽ. O bẹrẹsi wẹ, igbati o si mã rẹ ẹ gẽ o de erekuṣu kan. Erekuṣu yi kun fun dukia gbogbo, afi bi ẹni pe ṣe ni awọn ọlọṣa lo ibẹ bi ibi pipa nkan mọ si. O ri apoti kan bayi, bi o si ti ṣi i ṣe ni inu rẹ pupa wẽ fun owo kọrẹnsi onipọnun-kõkan o tun ri apoti kan, igbati o ṣi eleyi ṣe ni inu rẹ pọn dẹdẹ fun owo gõlu. Mo ro pe ṣe ni ọkọ kan rì ti igbi okun gba awọn nkan alumọni gbogbo si ori erekuṣu nã.

"Ko si pẹ pupọ ti o ri ọkọ awọn apẹja kan lokẽre. Were o bẹ lu omi o wẹ lọ ba a, igbati o si de ibẹ o bẹ awọn ọlọkọ nã ki nwọn lọ ba on gbe awọn apoti on ti o wa ni erekuṣu. Nwọn ba a lọ, igbati o si wadi ibiti on wà o ri i pe irin ọjọ meji l'o jẹ si ilu on.

"Igbati o di alẹ ọjọ keji, o de ile. Iyalẹnu l'o jẹ fun iyawo rẹ lati ri i werewere bẽ ṣugbọn igbati o ro ohun gbogbo ti o ṣẹlẹ, awọn mejeji dupẹ lọwọ Ọlọrun Ọba nwọn si pọ oró si ẹnu de Òbédiní ati ọrẹ rẹ.

"Ko ju oṣu keji lẹhin eyi ti ọba ku. Gẹgẹ bi aṣa ilu nã obinrin ko gbọdọ jọba ṣugbọn bi akọbi ọba ba jẹ obinrin ti o si gbeyawo, ọkọ rẹ l'o nilati jọba lẹhin iku ọba. Igbati o si tilẹ jẹ pe gbogbo enia l'o fẹran Òbédèjì ko si ariyanjiyan kan lẹhin ti ọba wọ aja, were ni nwọn fi on jẹ ọba.





"Oṣu kẹrin ti Òbédèjì ti g'ori oye ni Òbédìní pada de ilu wọn. Dide ti o de ãfin l'o ba lọ, ko mọ pe Òbédèjí ti jọba, ko tilẹ mọ pe ẹnikẹni gburo rẹ rara. Aiya rẹ tí o nja ati ẹri ọkan rẹ ko fun u laye ati simi o mu ki o yara lọ si ãfin lọ sọrọ fun iyawo aburo rẹ, iyawo Òbédèjí.

"Bi o ti de ọhun ti o lọ si ile ibiti ọba ti fun Òbédèjì ati iyawo rẹ ti nwọn sọ fun u pe nwọn ti kuro ninu ile nã ti nwọn si juwe ibiti iyawo ọba wà fun u l'o ti lọ ti o lọ purọ jọ. Bi iyawo Òbédèjí ti yọ si i ṣe l'o bẹrẹsi sọrọ, o ni 'Kabiyesi, ọjọ keji ti awa ati bãle yin kuro ni ile ni a ti pinya, emi ba apa ọna India lọ, mo de Silọn (Ceylon), Kalkọta (Calcutta) mo tilẹ de Ṣaina pẹlu (China), ọrẹ mi lọ si ilẹ Egipti (Egypt) on ta ọja rẹ ni ilẹ awọn Jũ ati Kọrã, ṣugbọn bale yin, ní apa Iwọ õrun Afrika ni on mã ti duro, mo si ro pe o de Ghana, Freetown ati Gambia. Ṣugbọn iyalẹnu l'o jẹ fun mi pe ko iti ipada de, ọran nã ya mi lẹnu pupọ. Ṣugbọn, Kabiyesi ẹ maṣe foiya ko ni pẹ de, ó nilati jẹ pe o ta ọja pupọ ni, ṣe ẹnyin nã kuku mọ Òbédèji aburo mi, yio ri i wipe on ta gbogbo ọja on tan ki o to wale. Ẹ ku lẽde rẹ. Kabiyesi'.

"Bayi ni Òbédiní sọ, irọ si ni, o ti ro pe aburo on ku ṣugbọn nigbati ó mã gbọ esi, ẹnu aburo rẹ l'o ti gbọ ọ. Òbédèjì jade ni iyara, o jade pẹlu ade lori, o ti di ọba, bi o ti dahun ti o ni, 'Emi Òbédèjì ni yi'. Òbédiní fẹrẹ wọ inu ilẹ lọ. Ọba nba ọrọ rẹ lọ o ni :

"'Òbédiní, Òbédiní, Ha ! Òbédiní !
O ti fi oju ida idile gbo' lẹ
O ba ẹbí jẹ, o ti tapa si ẹgun
O ba Ọlọrun wọ jakadi. O kọ ẹhin si Olodumare ti o da ọ.
Òbédiní, nibo ni ẹri ọkan rẹ wa, nigbati o ngbe ẹsẹ mi, ti o ngbe apa mi, ti o ngbimọ pẹlu ẹnikeji, ti ẹ ju mi si inu omi okun ?
Òbédiní, njẹ ẹmi rẹ iba wà loni, lái si mi ? Njẹ iwọ iba mã ri owo ṣòwò lái si mi ?

Ẹnyin alaimore ti ba ọmọ enia jẹ, ẹ sọ enia di ejo, sisa ni ẹ nmu enia sa fun õre ṣiṣe. Iba ṣe pe emi ni Ẹlẹda ni, ẹgún

bọ, ṣugbọn tani ninu wa ti o le ṣe afẹfẹ funrarẹ? Tani le sọ idi rẹ̀ ti o fi jẹ pe Iyunade ko loyun titi o fi di ọmọ ọdun marundiladọta ti o si wa jẹ pe o tun di ọlọmọ mẹfa? Njẹ Àdììtú ti o kuro lọdọ awọn enia rẹ̀ pẹlu aṣọ ti o dabi jọ̀wọ̀lọ̀ ọgẹdẹ fun akisa le mọ pe on tun le di ẹniti nlà, ẹniti nlu, ẹniti nni ile, ẹniti nni ọna, ẹniti nni mọto kitikiti? Lõtọ Àdììtú la ala pe on de ọrun tani mọ bi ọrun pãpã ti ri bi ko ṣe Ọlọrun Ọba. Njẹ Iyunade le mọ daju gãn pe Àdììtú ti on nbu pe ọrun rẹ̀ dabi ọrun ogongo tun le jẹ ọkọ on? Njẹ iba jẹ pe Òbédíní mọ pe Òbédèjí mã jọba iba sọ ọ sinu omi okun dan? Gbogbo iwọnyi kun fun Àdììtú ti Olodumare funrarẹ̀ dì eyiti o si jẹ pe Ọlọrun Ọba ti o di nikan lo le tu u.

Ọrọ ni eyi fun gbogbo enia ati pãpã fun awọn ọmọ ile iwe. Aiye yi ṣì kun fun ọpọlọpọ Àdììtú, bi a ba fojusilẹ dãdã a o le tu diẹ ninu awọn nkan ti Olodumare ti dì, bi a ti nsọ yi, ọpọlọpọ ni àrùn ọmọ enia eyiti apa ko iti ika, ọpọlọpọ dukia l'o wa ni isalẹ ilẹ ti a ko ti iri, bẽni a ko si le ka oniruru ẹrọ ti ọmọ enia le fi ori wọn ṣe ti nwọn ko iti iṣe. Ọrọ pupọ irọ l'o nmu wa, ọrọ mi ko ni gun lọ gbõrọ. Mo gbadura fun ẹnyin ti nka iwe mi pe iyẹ ki itan lara ẹiyẹ, aṣọ ko ni tan ni ile yin, Olodumare yio fun yin ni ibukun owo, ibukun ọmọ, ẹ ko si ni ṣai ni ohun ti ẹ o ma fi ṣe anfani lailai. O digba diẹ ná, ki ẹ ki gbogbo ile porogodo, ki Ọlọrun má kọ atunri. Ki Olodumarè jẹki a tun gburo ara wa.

ni iba mã hu jade lara alaimore dipo irun, ẹ̀gún ọ̀gàn on ọ̀ṣùṣú, ẹ̀wọ̀n ati ṣa-nga ni iba wà lara alaimore, ki ọmọ enia má ba sunmọ wọn. Nitori kini nwọn jẹ? Igi lasan ti ko ni ironu. Kini nwọn jẹ? Ọbọ lasan ti nti ori igi de ori igi. Kini nwọn jẹ? Akẽke ti gbogbo enia nsa fun. Ẹni ilẹ ni wọn, igbọnsẹ lasan lãrin ọmọ ti Olodumare da sinu aiye. Ẹ pe awọn ọlọpa mi fun mi, ẹ mu Ọ̀bédíní, ẹ di i tọwọtẹsẹ, ẹ so igi tutu nla mọ ọ lọrun ki ẹ ju u sinu ibu nla, ibu omi okun, ki awọn ẹja fi ẹran ara rẹ̀ ṣe ijẹ, ki nwọn jẹ ẹ ni ifun, ki nwọn jẹ ẹ ni ẹ̀dọ̀, ki nwọn jẹ ẹ ni apoloku patapata.'

"Bayi ni ọba sọ, Alaiyeluwa Ọ̀bédẹ̀jì, Iku baba yèyé, alaṣẹ ekeji oriṣa, atari ajanaku ti ki iṣe ẹrù ọmọde, ogbologbo ajẹ ti nfo rabarìbì, ọ̀ gbẹkẹlọ̀gun sọ ọmọ ajẹ ni ìkó pátákò ẹ̀fọ̀n ka-ka-ka ti ita aja lẹnu kọ̀ọ̀kọọbọ̀tọ̀, a gbe nla owo pamọ, o gbe kekere rẹ̀ s'ode, ọkunrin ogun, ọkunrin ti a fi iṣepe ọkunrin."



## IGBẸHIN ÀDÌÌTÚ-OLÓDÙMARÈ

Ọjọ meje ni gbogbo enia fi lọ sinu ile Ẹnúdùnjuyọ̀ lati gbọ itan ati ọrọ iṣiri lori orişirişi iwa. A ti sọ ti ọjọ mẹta, a o mã sọ ti ọjọ iyoku ninu iwe miran. Ko si aye nisisiyi lati mã sọ ọ-lọ.

Ẹ jẹki a wa wo bi ẹhin igbeyawo nã ti ri. Lọdun kini, inu tọkọtaya yi dun si ara wọn, ṣugbọn Iyunade ko loyun. Ki a ma sa ba a lọ bi ilẹ bi ẹni, fun odidi ọdun mọkandilogun ko loyun. Ṣugbọn awọn tọkọtaya meji yi fihan ni ohun ti o ṣe pataki julọ labẹ ile ẹni. Fun odidi ọdun wọnyi a ko ri Iyunade pẹlu ọkunrin miran afi ọkọ rẹ̀. Igbamiran pãpã awọn ọrẹ rẹ̀ ati awọn ibatan rẹ̀ ngba a niyanju ki o lọ ni ọkọ ìkọ̀kọ̀ pẹlu, ṣugbọn ko feti si wọn, Àdììtú-Olodumare pẹlu ko ye fẹran iyawo rẹ̀, ko ye kẹ ẹ ko ye gẹ̀ ẹ. A dahun a ni, "Bi Ọlọrun ba ri i pe ọmọ bibi yio ṣe wa ni rere ki o fun wa, bi o ba si ri i pe ko ni ṣe wa ni rere ki o maṣe fun wa. Iyunade mi ọwọn iwọ yi to ọmọkunrin o to ọmọbinrin fun mi."

Bakanna pẹlu ni, nwọn ko lọ si ile oniṣegun ju bẹ̃ lọ. Igbati nwọn ti lọ si ọdọ Dokita ti o yẹ ọkọ wo ti o wipe ko si nkankan lara rẹ̀ ti o le wipe ki ó má bimọ, ti o tun yẹ aya wo ti o wipe ko si nkankan lara rẹ̀ ti o le mu ki o má bimọ ni nwọn ti dakẹ ni tiwọn.

Awọn tọkọtaya wọnyi ti kọ ẹkọ wọn lati ọdọ awọn Oyinbo pe Ọlọrun ni iṣe ọmọ. Awọn ti nṣe iwadi nkan wi fun ni pe ni ilu nla London ti o tobi ju gbogbo ilu ode aiye yi ti o si ni dokita lọ yanturu, ẹgbẹgbẹrun tọkọtaya ni nwọn wà ti dokita wipe ko si nkan ti o le wipe ki nwọn má bimọ ṣugbọn ti nwọn ko bi. Idi rẹ̀ ni eyi, Ọlọrun gbọn ju enia lọ. On mọ oni O mọ ọla, O si mọ ẹgbẹrun ọdun ti mbọ. Bi o ba ri i pe ọmọ bibi ko le ṣe ẹnikan ni anfani ko nĩ fun u, bi o ba si ri i pe yio dara fun u, a fun u. Ko ju bẹ̃ lọ.

Igbati o sa di ogun ọdun gere ti Iyunade ti wọle ọkọ l'o dede loyun púyẹ́. O tilẹ to oṣu marùn ki on ati ọkọ rẹ̀ to fura

pe oyun ni. Igbati o si mã bí nkọ, o bi ibeji, ọkan, ọkunrin, ọkan, obinrin. Awọn ibeji wọnyi pe ọdun kan àì pe ọdun kan l'o tun loyun, igbati o tun mã bi, ibeji ni. Awọn ibeji ẹleyi pe ọdun kan ati oṣu mẹta l'o tun loyun miran, igbati o si mã bi eleyi, ibeji tun ni, bayi ni nwọn ni ọmọ mẹfa ni ile wọn. mẹta ọkunrin mẹta obinrin.

Igbati akọbi di ọmọ ọdun mejidilogun ni ogún bẹ silẹ larin ilu wọn ati ibomiran. Gbogbo ọmọkunrin, lati ọmọ ọdun mẽdogun de ãdọta nilati lọ si ogun.

Ati kekere ni Àdììtú-Olodumare ti nkọ awọn ọmọ rẹ̀ pe ohunkohun ti nwọn ba mã ṣe lode aiye, gbogbo agbara wọn ni nwọn nilati fi ṣe e. Ọkàn yi ni awọn ọmọ rẹ̀ ti nwọn lọ si ogun fi lọ. Awọn mẹtẹta ni nwọn dagba to lọ nigbati ija yi bẹrẹ awọn mẹtẹta ni nwọn si gba iyin awọn ọga wọn. Nwọn ntẹriba de ibi gongo, nwọn nṣiṣẹ wọn tọkantọkan, nwọn si nlo ọpọlọ wọn ni pipe ninu ogun yi. Igbati o si di oṣu mẹjọ ti ogun ti bẹrẹ ni ihin de lati oju ogun pe ọkan ninu wọn ti ku. L'oṣu kẹsan l'a tun gbọ pe ọkan tun ku pẹlu.

Ogun yi pari lẹhin ọdun kan ọmọ kan ṣoṣo l'o si ba awọn jagunjagun de ni ọjọ ti awọn ti ko ku pada bọ.

Ihin iku awọn ọmọ mejeji yi, ọjọ Jimõ ni nwọn mu u de, ọsẹ awọn onigbagbọ ku ọtunla, Nitori eyi, gbogbo ọjọ Jimõ ni Iyunade mã nranti awọn ọmọ rẹ̀ ti o si ma nsọrọ odi si Ọlọrun Ọba a dahun a ni: "Iwọ Ọlọrun Ọba, Olupese ni nwọn npe Ọ igbati O mọ pe inu rẹ ko dun lati fun mi ni awọn ọmọ wọnyi kil' O pese wọn fun mi si? Nwọn a ni Iwọ Olugbala, Iwọ ti O gba awọn ọmọ ẹlomiran la ninu ogun yi ti nwọn fi pada wa ba awọn obi wọn kil'awa ṣe ti O ko gba tiwa la? Nwọn mã npe ọ ni Onibu-ọrẹ, eyini ni pe ọrẹ Rẹ pọ o jinlẹ bi ibu omi okun, kini ṣe ti o jẹ pe ninu ọrẹ wọnyi o ko le fun wa ni awọn ọmọ wa mejeji yi tọkantọkan? Nwọn a ni Iwọ Olodumare eyini ni pe Iwọ ni O ni agbara nla ti O fi da gbogbo nkan nla nla inu aiye, kini ṣe ti O ko lo agbara yi fun awọn ọmọ wa? A wa wọn, wa wọn, wa wọn, a ko tete ri wọn, a gbadura, gbadura, gbadura, ẹnu fẹrẹ bo! Mo di ẹni ãdọta ọdun o din marun ni mo to bi ọmọ kini, mo ti bu di arugbo patapata ki





nto bi ibeji ikẹhin. Loni, dajudaju mo ti dá ogbó, ọmọ ko ṣẽ ṣe fun mi mọ, Olodumare, O fi ara Rẹ sú mi lati sin".

Bayi ni Iyunade ma nsọ nigbagbogbo lọjọ Satide. Àdììtú-Olodumare a mã tu u ninu, a mã ṣe ti ọkunrin, pẹlu ibanujẹ isalẹ ọkan nã ni.

Igbati o di ọjọ Satide kan, eleyi ti to oṣu kẹrin ti ogun ti pari, ni nwọn fi Àdììtú-Olodumare jẹ Oye kan ni ilu. Ọjọ ti o fi iwuye yi si jẹ ọjọ Satide. Igbati o di ọsan ni nkan bi agogo mejila, ni Àdììtú dede sa kuro loju ijo ti o wọle ti o bẹrẹ ẹkun o ni on ri ẹnikan ti o jọ akọbi on ọkunrin ti ogún ti pa o bẹrẹsi sọrọ lohun arò o ni "A! Iwọ Ọlọrun Ọba, Iwọ Ọlọrun Ọba, Iwọ Ọlọrun Ọba! Bawo ni iba ti dun to ki a wipe, awọn akọbi mi ọkunrin wa lode aiye lọjọ oni? Bawo ni ayọ nã iba ti to ki a wipe bi mo ti njo ni awọn nã njo? Bawo ni inu mi iba ti dun to ki a wipe bi mo ti nyọ ni awọn nyọ? Bawo ni iba ti dun to ki a wipe mo ri awọn ọmọ mi ninu agbada nla, ki nri wọn pẹlu àtàtà ọ̀yàlà, ki nri wọn ki awọn na ri mi, ki nwo ẹhin bayi ki nri awọn ọmọ mi gbogbo?" Bi o ti wi bayi tan o b'ojuwo ẹhin rẹ. Kil'o ma ri! O ri awọn ọmọ rẹ ọkunrin mejeji, nwọn wọle. Aiya rẹ̀ ja lati ri wọn nitori o ro pe nwọn ti ku ati pe oku ni wọn ti nwọn wọle.

Igbati o pẹ ṣa awọn ọmọ bẹrẹ ihin iro bi o ti jẹ pe igbati awọn ọta yinbọn si ọkọ ofurufu ti nwọn wa ninu rẹ̀ awọn ti lo ẹrọ ti o njẹki enia mã lọ silẹ jẹ̃ ti awọn si bọ si ibiti ko jina si ilu kan. Bẽ ni akọbi ti nwọn kọ ro pe o ku ti ṣe la, bẽ nã si ni ekeji ṣe la pẹlu. Awọn mejeji ti ri ara wọn to oṣu kan ki ogun to pari. Igbati ogun pari tan ko si ẹniti o ṣe eto ati mu wọn wa si ile nitori awọn ọga wọn ti ro pe nwọn ku, nwọn si nilati ṣiṣẹ ki awọn ri owo wọ ọkọ wa si ilu wọn.

Ẹnyin ọmọ enia, bayi ni a o pari iwe itan ti eleyi sí, mo si fẹ ki ẹ wo orukọ ọkunrin ti o ṣe pataki ninu iwe nã, Àdììtú-Olodumare. Aiye wa yi, kiki adiitu ni, ogunlọgọ ọkẹ aimoye nkan ni o wa ninu aiye yi ti o jẹ pe Olodumare nikan ni o mọ itumọ wọn. Kọkọrọ aiye, ọwọ Ọlọrun ni mbẹ. Nibo ni ọgbọn enia tilẹ ti ide? A gbọ pe Àdììtú wa ninu ọkọ ofurufu, ọmọ enia lagbara ati lo afẹ̃fẹ lọna ti yio fi mã gbe wọn kiri lái ja

Nelson books give sound education 978 126 238 9

ÌRÈKÉ-ONÍBÙDÓ

D.O. FÁGÚNWÀ

# ÌRÈKÉ-ONÍBÙDÓ



D.O. FÁGÚNWÀ

# ÌRÈKE-ONÍBÙDÓ



" Emi Àrò-gìdìgbà ti ìṣe olori ẹja inu omi."

# ÌRÈKÉ-ONÍBÙDÓ

## PẸLU ỌPỌLỌPỌ ÀLÀYE

Lati ọwọ

**D. O. FAGUNWA, M.B.E.**

Ẹniti o ṣe iwe " Ogboju-ọdẹ ninu igbo irunmalẹ," " Irinajo," ati " Igbo-Olodumare."

Nelson Publishers Limited

Published by
Nelson Publishers Limited
*in association with*

Evans Brothers (Nigeria Publishers) Limited,
Jericho Road, PMB 5164, Ibadan, Nigeria.
Tel: 02-2414287, 2414394, 2413708

E-mail: evans@skannet.com
evans@evanspublishers.com.ng
Web: www.evanspublishers.com.ng

© Nelson Publishers Limited 2005

**First published 1949**

Reprinted 1950 (twice), 1951, 1952, 1953, 1954, 1955, 1956 (twice), 1957 (twice), 1958, 1959(twice), 1961, 1964, 1965, 1968, 1970, 1971, 1973, 1975, 1976, 1977, 2005, 2006, 2007, 2008

All rights reserved. No part of this publication may be reproduced, stored in a retrieval system, or transmitted in any form or by any means, electronic, mechanical, photocopying, recording or otherwise, without the prior permission of Nelson Publishers Limited.

ISBN 978 126 238 9

## ỌRỌ AKỌSỌ

Ẹni Ọwọ R. A. McL. Davidson, C.M.G., ti o jẹ Alakoso Ẹkọ ni Nigeria lakoko yi ni ẹniti o jẹki nkọwe yi, bayi ni: igbati mo pari iwe mi, " Igbo Olodumare : apa keji Ogboju Ọdẹ Ninu Igbo Irunmalẹ " ti mo kọwe wipe mo fẹ fi iwe nã juba Ẹni Ọwọ nã, ọrọ ti o sọ sinu iwe ti o fi gbà bẹ̃ fun mi ni iṣiri tobẹ̃ ti mo tun fi wipe afi bi mo ṣe iwe miran dandan. Ọgbọn ni eleyi fun awọn aṣãju gbogbo, ẹ̀rín lasan lati ẹnu ẹniti o jẹ Aṣãju ṣe pataki fun awọn ọmọ ẹhin, igbakigba ti a ba ri i wipe Olodumare gbe wa si ipo pataki ẹ jẹki a mã fi ipo nã ṣe awọn ọmọ ẹhin wa lõre, mo dupẹ lọwọ Ẹni Ọwọ R. A. McL. Davidson, C.M.G., lọpọlọpọ.

Iwe yi wa fun gbogbo awọn ti o ba mọ iwe Yoruba ikà dãdã, iwe itan fun awọn ti o wa ni ipo iwaju ni ile ẹkọ kekere, ati kikọ́ ijinlẹ Yoruba fun awọn ti o wà ni ipo iwaju ni ile ẹkọ giga.

**D. O. FAGUNWA.**

# FIFIJUBA

Mo ti gba aṣẹ lọdọ awọn wọnyi pe mo fi iwe yi juba won:

Miss G. Plummer, M.B.E., obinrin kini ti o de ipo Igba Keji Alakoso Ẹkọ ni Nigeria, ẹniti o ti fi gbogbo ara ṣiṣẹ fun ọdun pupọ lãrin wa.

Bişọbu S. C. Phillips, M.A., L.Th., ẹniti o jẹ ẹni kini ni apa Iwọ Õrun Afrika ti o jẹ pe nigbati nwọn mã ṣe ifijọye rẹ gẹgẹ bi Bişọbu ti Ijọ Anglican, nwọn ṣe e ni ori ilẹ wa gãn, on pãpã ti kọwe fun kika ri.

Ọgbẹni W. T. Mackell, O.B.E., ẹniti o jẹ olori awọn ti nyẹ ile ẹkọ wo ni Nigeria, o jẹ ẹniti o fẹ ki ede Yoruba mã lọ siwaju.

Alufa I. O. Ransome-Kuti, M.A., olori ẹgbẹ gbogbo awọn olukọ ni Nigeria, on l'ọ si ṣe aṣoju Nigeria ninu Igbimọ pataki ti o ṣe eto fun ile ẹkọ miran ti o ga ju eyikeyi ti a ti ni ni Nigeria lọ, Ọgbẹni Elliot ni Alaga Igbimọ nã.

Rachel Fagunwa, iya ẹniti o kọwe yi.

# DEDICATION

*Dedicated, by permission, to the following:*

*Miss G. Plummer, O.B.E., Deputy Director of Education (Women), Nigeria, who has given many years of meritorious service to the country.*

*The Right Reverend Bishop S. C. Phillips, M.A., L.Th., the first Anglican Bishop on the West Coast of Africa whose consecration took place on the soil of Africa.*

*W. T. Mackell, Esq., O.B.E., Chief Inspector of Education, Western Provinces, Nigeria, who is keenly interested in the development of Yoruba literature.*

*The Reverend I. O. Ransome-Kuti, M.A., President of the Nigerian Union of Teachers, who was the Nigerian representative on the Elliot Commission for Higher Education.*

*Madame Rachel Fagunwa, the author's mother.*



# IFIHAN


| | |
|---|---|
| Pipade awọn abami ẹda .. .. | 1 |
| Alabapade Ìrèké-Oníbùdó .. .. | 17 |
| Ọjọ keji alabapade Ìrèké-Oníbùdó .. | 45 |
| Aròọ̀gìdigbà ti iṣe olori ẹja inu omi .. | 63 |
| Igbesi aiye mi ni ilu àlúpàyídà .. | 76 |
| Ìtánforítì ti ngbe inu iho ilẹ .. .. | 103 |
| Itanforiti ati oniruru iwa ọmọ enia .. | 124 |

# PIPADE AWỌN ABAMI ẸDA.

Ẹnyin Ọrẹ Mi,

Ẹ ku atijọ o, ẹ jẹki a jọ ṣe aṣaro bi meji tabi mẹta, mo ni nkan kan lati sọ fun yin, nitori mo ranti loni, bi ẹni pe àná ni nkan nã ṣẹlẹ ni, mo ranti aiye atijọ, nigbati nko ju kekere lọ, ti mo mã nba baba mi lọ si oko wa lọhun, ni oke ẹgàn wa, nitori lati igbati mo ti wa ni kekere ni baba mi ti sọ mi si ile iwe, ṣugbọn nigbati a ba gba isimi ni ile iwe, emi a ba oko wa lọ, akoko yi ṣe pataki pupọ ni igbesi aiye mi, akoko igbadun patapata gbã ni; itan ti ng o sọ fun yin loni jẹ itan nipa ọkunrin kan ti mo ba pade nigbanã; akoko didun ni oko wa, nigbati a ba ko agbado tutu lu ina, ti a nfi ehin họ agbado tutu jẹ, bi a ba jẹ agbado tutu ni ọsan à mã jẹ iyan lalẹ, iyan titobi ori ewe ọgẹdẹ, ti o mã nṣe inu wa bi apo ekurọ, mo si tun ranti dãdã pẹlu pe takute wa a mã pa ẹran, awa a mã ṣe alabapade igbin, olú a si mã hu kãkiri ninu oko wa.

Odo nla kan ṣan lọ ni ẹba oko baba mi, ninu odo yi ni mo si ti mã npa ẹja, ki iṣe pe mo ni àwọ̀n ni, iwọ̀ ni mo fi mã npa ẹja temi, bi mo ba ti mu iwọ mi ti mo yi odo nã lọ inu mi a mã dun pupọ afi bi ẹni pe mo wà ni Paradise ni.

Baba mi ṣe e pupọ fun mi, nitori o mọ ailera mi, nigbati a ba lọ si inu oko ni owurọ ti mo ba mu ọkọ temi ti mo nro oko lọ, a mã ṣe akiyesi mi, igbati o ba si di pe mo bẹrẹsi duro, ti mo nfi ọwọ tẹ ìbàdi, ti ó woye pe idi nro mi a ni ki nlọ si abẹ igi ki nmã simi, nigbati õrun ba si bẹrẹsi ran pupọ ti o di pe ọsan

npọn, baba mi a wi fun mi pe ki nmã lọ si ahere wa. Bi o ba si di oju alẹ, a wi fun mi pe on yọ̃da fun mi ki nba odo ẹja lọ.

Ọba ni Olodumare fi awọn agbẹ jẹ si inu oko, onirũru awọn nkan ti o ni iyi ni oju awọn ara ile, yẹpẹrẹ ni loju wọn: igi gbigbẹ kò jamọ nkankan, ewe ko ni iyi rara, onjẹ si pọ lọ yanturu. Bi ẹnikan ko ba mọ bi Olodumare ti lagbara to ki oluwarẹ lọ wo onirũru nkan abami ti mbẹ ninu oko, bi igi giga ti mbẹ bẽni igi kukuru mbẹ, bi ẹiyẹ kekere ti mbẹ bẽni ẹiyẹ nla mbẹ, ibiti erin wà ibẹ ni ijapa wa, ibiti ejo ti nsare kiri ni igbin rọra nrin lọ, alantakun nranwu, ikán nba iṣẹ lọ ni ori okiti ọgan, awọn ẹiyẹ miran ngbe inu igi, omiran ngbe iho ilẹ, omiran ngbe inu itẹ, adan ndori-kodo sun, owiwi nkigbe kiri lãrin oru, adaba nsọ akoko fun awọn agbẹ, on duro bi agogo ti Olodumare sọ lọjọ̀ sãrin igbẹ, igbati awọn agbẹ ba jẹun tan, nwọn a bu omi tutu mu.

Laiṣeaniani ẹ ko ni ṣai ranti owe awọn agba ti o wipe melo ni a o ka ni ehin Adepele, tinu ọ̀rún, tode ọ̀jọ, bẽni ojilenirinwo erigi l'o fi ori mulẹ laiyọ, mo ro pe eyiti mo sọ nipa awọn agbẹ wọnni to nisisiyi, ẹ jẹki nmã ba ìtan mi iyoku lọ.

Bayi ni: igbati a gba isimi idaji ọdun nigbakan bayi, mo mura o di oko, emi ati aburo mi obinrin ti iya mi bi tẹle mi gãn, Mary, nigbati a si nrin lọ ti a de eti omi nla kan bayi ti o wà ni ọna oko wa, a ri i pe omi nã kun pupọ nitori akoko ojo ni, nigbati mo si ri eyi mo wi fun aburo mi wipe ki o pada si ile, emi bọ si inu odo, mo wẹ kọja lọ ni temi, bi mo ti rin diẹ lẹhin eyi mo pade ọkunrin kekere kan, ko ga ju ibadi mi lọ, bẽni emi pãpã kuru pupọ nigbanã, on nlọ niwaju emi mbọ lẹhin, igbati o ṣe o duro emi





nã si duro ni temi nitori ẹru nba mi, nko kuku ri ọkunrin ti o ri rugudu bẽ ri, ko si si enia nibiti mo wa yi, mo rọra duro mo nwo nkan ti ọkunrin nã mã ṣe.

Ko pẹ pupọ ti mo duro ti mo nwo iwaju ti nko ri ọkunrin nã mọ, mo tun kọju si ọna mo nlọ. Bi mo tun ti rin diẹ si iwaju afi igbati mo wo ẹhin ti mo tun ri ọkunrin nã ti o ntẹle mi, igba nã ni mo si to ṣe akiyesi pe oju kan ṣoṣo ni o ni, ọkan nã wà ni iwaju rẹ̀, o dabi digi kekere ti awọn ọdọmọbinrin mã nfi si inu apamọwọ wọn: mo gbiyanju ki nkigbe ṣugbọn ohọn mi ko yipada rara, nko si le sọ gbolohun ọrọ …n, mo ba bẹrẹsi sare lọ, nigbati mo si mã wo ẹhin mi mo ri awọn ọkunrin meje rugudu ti nwọn nsa tẹle mi, emi nã tubọ mura si ire ṣugbọn were ni nwọn ba mi ti nwọn mu mi ti nwọn si bẹrẹsi fà mi lọwọ wọ inu igbo lọ.

Nigbati a kuro ni oju ọna tan ti a rin to iṣẹju marun ninu igbo nko ri awọn rugudu wọnni mọ ṣugbọn dipo wọn mo ri ọkunrin kan, o duro niwaju mi mo si tun ri ọkunrin alakisa kan ni apa ọtun bayi. Eyiti o duro niwaju mi yi dara tobẽ ti nko iti iba iru rẹ̀ pade ri, o wọ ẹwu funfun nini, o de fila gõlu, o wọ bata gõlu, oju rẹ̀ ndan bĩ digi, ehin rẹ̀ funfun bi oju õrun, ara rẹ̀ dabi àṣẹ̀ṣẹ̀yọ eweko eti odo ti nfi ogo Olodumare han ni, aṣọ funfun ti o wọ nì kan a lọrun ẹsẹ, apa ẹwu rẹ̀ kan a ni ọrun ọwọ, bẽni ọpa ti ọkunrin nã fi ti ilẹ, ti diamondi ni. Nko ri iru rẹ̀ ri, ko jọ ọmọ enia loju mi.

Nigbati o ri mi o bu si ẹrin, o fi ọpa ọwọ rẹ̀ nì kan mi lori, bi o si ti ṣe bẽ ni mo ri i pe ọkan mi balẹ ti aiya mi ko ja mọ o ni:

"Iwọ ọmọde yi, mo ba ọ yọ pupọ pe Ẹlẹda ti pinnu lọkan rẹ̀ lati lo ọ fun awọn ọmọ araiye, Olodumare

ni o fi iṣẹ nã ran ọ, ki iṣe ọwọ ọmọ enia ; lõtọ ọmọde ni ọ, ṣugbọn ẹyin ni ndi akukọ, igba ewe ni nñ igba agba han, gbongbo ni pataki lara igi, orisun omi ni iṣe alakoso omi, akoko yi ni ki o ti kọ ile rẹ le ori apata, nitori Olodumare ni apata, yanrin ni awọn nkan yoku, gbe ọjọ aiye rẹ le Ọlọrun Ọba lọwọ, ṣugbọn maṣe gbagbe, aiye mà ṣoro o, nitori aiye ki ifẹ õtọ, nwọn a mã jẹ eke bi ẹni njẹ ẹran, bẽni õtọ ni Ẹlẹda rẹ fẹ ki o mã sọ, nitori biotilẹjẹpe aiye fẹran awọn eleke ifẹ nã ki iduro pẹ, aiye nã ni imã bi eleke lulẹ, olõtọ ki itete ni iyi, ṣugbọn nigbati o ba ni iyi tan a joko bi ọba, a duro pẹlu ibalẹ ọkan, a mã rin bi ala-gbara, nitori kini nkọ ? Nitori ko ṣe nkan ìkọ̀kọ̀ pamọ si ọwọ ẹnikẹni, ko ba ẹnikẹni si ni idi àbòsí, o le da ẹjọ ẹbi fun ẹlẹbi, o le da ẹjọ are fun alare, nitori kò gba abẹtẹlẹ lọwọ enia, kò ṣe ojuṣaju awọn ọmọ araiye, bi o si ti wù ti okun eke yi to, ọbẹ àlòkù ni olododo fi ige e. Iforiti ṣe pataki pupọ, kiyesi ayika rẹ, wò bi awọn igi wọnni ti ri, ọkan kò ba ekeji mu, nwọn ga ju ara wọn lọ, si ṣe akiyesi pẹlu pe awọn rugudu ti o mu ọ de ọdọ mi ko ga to mi, wo ẹniti o duro si apa ọtun rẹ, wo akisa ẹgbẹ rẹ̀, o yatọ si ohun alumọni ti mbẹ ni ẹgbẹ mi, aiye ko dọgba, nitorinã nkọ, bi nkan ti iwọ ri ko ti dọgba nì bẽ nã ni igbesi aiye ọmọ enia ko dọgba, iforiti ni ẹnikẹni le fi jogun aiye, oniforiti yio mã duro nibiti awọn ẹni nla ti nduro, ṣugbọn onirẹwẹsi yio mã wà lãrin awọn ero ẹhin lailai. Mo si tun fẹ ki o kiyesara nipa ibọwọ fun agbalagba, jọwọ mo bẹ ọ gidigidi, abawọn ni igberaga, maṣe jẹki o ta si ọ lara, bi ó ba ti ta si enia lara oluwarẹ̀ gbé, ẹsẹ nã duro bi ohun ìkọ́sẹ̀ pataki ti Eṣu fi si oju ọna awọn ọmọ araiye, bẽni, emi ni mo wi fun ọ, iparun ni yio gbẹhin eṣu, ni ọjọ ti Olodumare ba mã ṣe idajọ





awọn ọmọ enia, Eṣu yio ba ara rẹ̀ ninu ibanujẹ aini-pẹkun, ṣugbọn ki ilẹ to pa òṣìkà ti ẹni rere ti lè bajẹ. Nitorinã maṣe jẹki Eṣu ta abawọn igberaga si ọ, ṣugbọn irẹlẹ yatọ si omugọ, maṣe jẹki irẹlẹ rẹ mu omugọ lọwọ, enia ko le wipe nitori on jẹ onirẹlẹ ki nwọn fi si ipo olori ki o fi nkan olori silẹ ki o mã ṣe ti ọmọ ẹhin, bẽni enia ko si le wipe on jẹ onirẹlẹ ki o sọ ara rẹ̀ di ori-ãtan ki gbogbo awọn ọmọ araiye mã da iwọsi le e, bakannã si ni pẹlu, bi enia ko ba ni igbẹkẹle si ara rẹ̀ pe on le ṣe eyi tabi eyini o ṣoro ki o to le ṣe nkankan. Ki a gbẹkẹle ipa ti Olodumare fun ni yatọ si igberaga, nitori ọta pataki ni iyemeji jẹ fun awọn ọmọ araiye, o kò gbọdọ jẹki ọta nã ri ọ gbe ṣe.

" Iwọ ọmọ, ṣe akiyesi ẹniti o duro ni apa ọtun rẹ yi, wo o dãdã, on ni ng o ran si ọ ni ẹhin ọla, nigbati iwọ ba kuro ni kekere, ti iwọ ba di ọkunrin, eleyi ni yio tọ ọ wa, ti yio sọ bi aiye on ba ti ri fun ọ. Mura si ẹkọ rẹ, ki o pese silẹ fun ọjọ ti nbọ, nitori akoko nbọ ti baba rẹ ti iwọ nwo nì yio pa oju de ti ko ni la a mọ ti yio si fi gbogbo iṣẹ rẹ̀ silẹ fun ọ lati ṣe.

" Njẹ mã lọ nisisiyi, ki Olodumare ṣe igbesi aiye rẹ ni rere ; ba mi ki baba rẹ, si ki iya rẹ pẹlu, ba mi ki awọn aburo rẹ, ati pãpã Mary ti nwọn bi tẹle ọ gãn ẹniti o duro le gongo ibi ori ẹmi rẹ o digba o."

Bayi ni ọkunrin nã sọ fun mi o si fa mi le ọkunrin alakisa nì lọwọ o ni ki o mu mi wa oju ọna, on nã si ṣe bẽ, ṣugbọn nigbati mo to de oju ọna ni mo to bẽre bi ọkunrin ti o nmu mi lọ nã ti ṣe de ibiti mo ba a o si wi fun mi pe mimu ni awọn ti o mu mi mu on nã, eyini ni awọn ẹda rugudu wọnni ti nwọn ni oju kọkan ni iwaju wọn. Nigbati a ja oju ọna tan mo ṣebi ọkunrin alakisa nã mã pada ni ṣugbọn ko ṣe bẽ o kọju si ọna ìbiti mo nba lọ a si jọ nrin lọ. A rin

titi a fi de ìyànà oko tiwa ti mo yà ṣugbọn on kọja siwaju.

Nigbati baba mi ri mi o ya a lẹnu pupọ nitori odo kun rekọja ko si ni ero pe mo le wa si oko rara. Nigbati mo ko ti mo ro fun u bi mo ti ṣe ri awọn rugudu rugudu gbogbo ti nwọn le mi titi ti nwọn mu mi wọ inu igbo lọ titi mo fi lọ ba abami ẹda kan lãrin igbo ẹnu tubọ ya a ẹru si ba a, o wi fun mi pe ki nṣe ẹnu mi jẹjẹ ki nmá mã ro ọran nã kiri ati wipe ki iṣe ohun gbogbo ti ọmọde ba ri ni o nfi ẹnu rẹ sọ.

Inu mi dun pe agbado tutu gbo gãn ni mo de oko mo si jẹ agbado tobẽ ti o fi jẹ wipe ibiti mo ba nyagbẹ si bayi, gbangba ni mo nwo ẹyọ agbado. Oko dun nigbati mo nsọrọ yi, ara awọn ohun ọgbin tutu nini, iṣu ti lọ́ mọ ẹ̀yá iṣu ti bò ruru, ewe ila ri gbẹ̀rẹ̀gẹ̀dẹ̀ gbẹrẹgẹdẹ, ẹfọ tẹ̀tẹ̀ ri gbògagbòga, ogunmọ ri gbẹgẹ-gbẹgẹ, elegede yọ ọwọ ṣaraṣara, ewe ọ̀sùn ri gbàràgàdà gbaragada, õyọ dudu mirinmirin, akengbe fà bo ilẹ, olú si bẹrẹsi hù lara awọn oku igi—A! Akoko pataki ni eyi ni oko baba mi. Lẹhin igbati emi nã jẹun tan, mo wọ igbo ẹ̀bìtì lọ.

Nigbati o di oju alẹ mo pada wa si abà wa, mo lọ si ọdọ ẹgbọn mi agba ọkunrin ti o jẹ ọmọ iya baba mi, mo wi fun u pe mo nfẹ dẹ takute ó si gbe ọkan fun mi, mo gbe e lọ si inu oko wa ni inu agbado, mo dẹ ẹ si oju ọna awọn ọ̀yà ti njẹ agbado wa, nigbati o di owurọ ọjọ keji takute nã kò ré nitori biotilẹjẹpe awọn ọya wa pa agbado, nwọn ko rin si oju takute mi. Ṣugbọn nigbati o di owurọ ọjọ kẹta ti mo lọ wo o mo ri i pe o ti ré o ti mu ọya ni apa, o ti ge apa ọya, ẹranko nã si ti gbe kukute iyoku lọ.

Awọn ẹbiti mi ti bẹrẹsi pa eku ni ọjọ keji ti mo ti dẹ wọn, eyiti mo si dẹ si ẹ̀bẹ̀ àlà ni eti oko kòkó wa





pa ọkẹrẹ ni ọjọ kẹta. Nigbati o di ọjọ kẹrin ti mo ti de oko ni ọkan ninu awọn ọdẹ ti mbẹ loko wa pa agbọnrin kan ni inu oko o si gbe e wa si abà o kun u o si fun awa ti a jẹ ọmọde ni ọpọlọpọ ìjànjá ẹran ti a sun jẹ ṣugbọn o fun awọn agba ni ẹran ti o pọ ju tiwa lọ. Eyiti o fi fun baba mi pọ ju ti gbogbo awọn ti a jọ ngbe abà, nitori baba mi ni olori oko wa. Ṣugbọn o dun mi lati sọ pe nkankan ṣẹlẹ si mi lọjọ yi ti o dun mi gidigidi, ibiti mo ti nti odo bọ̀ mo fọ akengbe ṣugbọn baba mi ko ba mi wi pupọ o ni nki iṣe bẽ ati wipe o ṣèṣì ni, ṣugbọn o kilọ fun mi pe nko gbọdọ ṣe bẽ mọ ati wipe ọjọ ti nba tun ṣe bẽ on o nà mi.

Bẽni mo sa gbadun oko nã titi o fi di pe mo pada wa si ile. Igbati a fi mã wa ile odo ti o wà lọna oko wa ti fà diẹ, nwọn ti ṣe afara le e lori ori afa nã ni a si ba kọja nigbati a nbọ.

Ṣugbọn kini igbẹhin ẹniti mo ri lọna oko ti o fi ọpa kan mi lori? Lati ọjọ ti mo ti ri i nko tun fi oju ba a mọ di bi mo ti nsọrọ yi ṣugbọn mo nri i loju ala ng o si sọ bi mo ti ṣe nba a pade loju ala mi.

Lẽkinni, mo ri i gẹgẹ bi o ti ri gãn lọjọ ti mo ri i lọna oko, ṣugbọn kò mu ọpa lọwọ mo si ri iyẹ ni apa rẹ. O sunmọ mi, o gbe mi le ejika rẹ o si bẹrẹsi fò lọ. Nigbati o pẹ o gbe mi lọ si oke tobẽ ti mo bẹrẹsi rò wipe mo ti kọja sakani ibiti aiye wa ati wipe mo ti nsunmọ agbegbe ode ọrun. Nigbati o ṣe, o duro si ofũrufu emi nã wà ni ejika rẹ, o ni ki nwo ilẹ mo si wo o, o bẽre ohun ti mo ri mo si wi fun u pe nko ri nkankan ati wipe gbogbo ilẹ ri bakannã loju mi. Lẹhinnã o ki ọwọ bọ apo rẹ nigbati o si mã fa ọwọ yọ o mu digi ti nwọn mã nfi si oju o fi i si oju mi o tun wi fun mi ki nwo ilẹ mo si wo o nigba yi mo ri gbogbo aiye porogodo mo si wi fun u pe gbogbo aiye ni mo ri,

o si wa bi mi ni gbolohun ọrọ kan bayi o ni, " Iwọ ọmọ mi, nję nkan le tobi to bayi ki ó má ni alakoso ? " Emi nã dahun mo ni " Agbẹdọ o, nkan ko le to bi iru eyi ki o wà ni aini alakoso". O si tun bi mi siwaju si i o ni, " Nję bi aiye yi ba ni alakoso tani alakoso rẹ̀ ? " Emi nã si tun fesi mo ni " Olodumare ni alakoso aiye." O wa tun rẹrin o dahun o wi bayi pe : " Mã lọ, maṣe gbagbe eyiti o sọ fun mi nì, fi i si ọkan titi ọjọ aiye rẹ." Nigbati o wi bayi tan o gbe mi fo pada wa si ilẹ o si fi mi silẹ o ki mi pe o digbõṣe, o si nlọ, o nki mi bi o ti nlọ, bẽni emi nã nda a lohun, mo da a lohun titi mo fi ji.

Nigbati mo ji tan ti mo ri i pe ala ni mo la ẹru ba mi pupọ ṣugbọn nko tun gburo ọkunrin nã ni oju ala mọ titi fi di ọdun kẹta.

Nigbati o di ọdun kẹta lẹhin eyi mo tun sun mo ri i loju ala, mo ri i bi mo ti ri i ni iṣãju o si tun gbe mi le ejika o ngbe mi lọ, nigbati o de ibi ofũrufu ijọsi ko duro, nigbati o si tubọ fo si i o de ibi imọlẹ nla kan bayi, bi mo si ti tẹjumọ imọlẹ nã ni mo ri i ti o yipada ti o di ile kan. Ọkunrin nã tun gbe mi wọ inu ile ti mbẹ ni ofururufu nã lọ. Nigbati mo wọ inu rẹ̀ mo ri i pe gõlu ni nwọn fi ṣe ilẹ ibẹ patapata ẹru si ba mi ati fi ẹsẹ tẹ ilẹ inu ile nã ṣugbọn ẹniti o gbe mi wọ ibẹ wi fun mi ki nmã rin bi mo ba ti fẹ emi nã si nṣe bẽ.

Lẹhin eyi o mu mi wọ iyãra kan ninu ile nã lọ, nigbati mo de ọhun o ṣi ferese ibẹ o si mu mi lọ si ibi ọkan ninu awọn ferese wọnni, o ni ki nyọ oju si ita emi nã si ṣe bẽ.

Nigbati mo ṣe bẽ mo ri odò ṣiṣan kan ni isalẹ ibẹ ko si dabi ẹni pe o jina si mi to bi mo ti ni ireti. Ọkunrin nã si bi mi bi mo ba mọ ibiti odo nã wà mo wi fun u pe nko mọ ọ, lẹhinnã o sọ fun mi pe ile aiye





ni. O yà mi lẹnu pupọ pe aiye sunmọ wa nibiti a wà nã to bẽ nitori a ti fo jina pupọ ju loju mi. Ọkunrin nã wa tun sọ fun mi pe ki nmã wo omi ti mo ri nì ati wipe ki nṣe akiyesi ohun gbogbo ti mo ba ri emi nã si tẹjumọ ilẹ on jade kuro ninu iyãra nã o ti ilẹkun mọ mi sinu ile o ba ibomiran lọ.

Ko pẹ pupọ ti mo nwo ilẹ bayi ti mo ri ọkunrin arugbo kan ti o wa lati wẹ leti odo nã, o gbe apo owo kan lọwọ. Nigbati o wẹ̀ tan, o lọ, o gbagbe apo owo nã silẹ.

Nigbati o ṣe, inaki kan jade ninu igbo o tu apo owo nã o bẹrẹsi fọ́n owo inu rẹ̀ danu ; nigbati o fọ́n diẹ danu ninu owo nã o fi iyoku silẹ o ba inu igbo lọ.

Nigbati o lọ tan ọkunrin kan wa lati wẹ̀, nigbati o de odo o ri owo ti o ṣẹkù sinu apo o gbe e, o salọ.

Bi o ti lọ tan ni arugbo kan wa wẹ̀ ni odo nã, ibiti o si ti nwẹ̀ ni ẹniti o kọ gbe owo nã wa ti o gbagbe rẹ̀ de pẹlu ibọn, o ri arugbo ti o nwẹ o bẽre owo lọwọ rẹ̀ onitọhun si wi fun u pe on ko ri nkan ti o jẹ owo nigbati on de odo. Ọkunrin yi ko gba a gbọ o ni irọ ni, were o yinbọn lu u o ba tirẹ̀ lọ.

Lẹhin eyi nko ri ẹlomiran mọ ko si pẹ pupọ nã ti ẹniti o mu mi wọ iyãra ṣi ilẹkun lẹhin mi ti o wọle de. O bi mi lẽre wipe ki nsọ nkan ti oju mi ri leti odo nã mo si sọ gbogbo rẹ̀ patapata fun u. Lẹhin eyi o wa ṣe ibẽre kan bayi o ni : " Da ejọ nã, tani jẹbi ninu gbogbo awọn ti o wa si eti odo nì."

Mo gbiyanju lati da ẹjọ nã ṣugbọn o ni nko da a dãdã o dahun o ni :

" Iwọ ọmọkunrin, awamaridi ni iṣẹ ọwọ Olodumare ; enia ki iri gbongbo okuta ; a ko le ri idi Ẹlẹdạ ẹni ; enia ko le mọ bi ode ọrun ti ṣe bẹrẹ, ọmọ araiye kò lagbara eyini ; awọn ọmọ araiye nriran baibai ninu

awojiji, ãla wà lagbedemeji aiye on ọrun. Ko si ẹniti o jẹbi ninu awọn ti iwọ ri leti odo wọnni; ẹniti o gbe owo wa eti odo, ki iṣe owo rẹ ni, o ji owo nã ni. Inaki ti o jade lati inu igbo ti o bẹrẹsi fọn owo danu, owo ti o jẹ owo aiṣododo ninu owo nã ni o fọn danu ti iwọ ri nì. Ọkunrin ti o wa si eti odo ti o ri iyoku owo nã gbe, baba nla baba rẹ ni o ni owo yi ni ibẹrẹ patapata nwọn si ti bẹrẹsi fi owo nã ṣowo lati ọmọ de ọmọ. Ọkunrin ti o wa wẹ ni odo ti ẹniti o ji owo wa pa, baba iya nla rẹ l'o pa iya baba nla ole laiṣẹ, Olodumare a si ma bẹ ẹṣẹ baba wo lara ọmọ, a tun mã san õre baba fun ọmọ pẹlu, ere olukuluku mbẹ lọwọ Ọlọrun Ọba, enia ko le ṣiṣẹ ibi ki o jere nkan rere, ẹniti o gbin èbù ika ori ọmọ rẹ ni o gbin i le nitori ori awujẹ ni awujẹ fi igbe ilẹ jade, ori okiti ọ̀gán ni òkìtì ọ̀gán njin le ẹniti o ba ṣe ibi ni ibi mã nlepa. Nitorinã ki o fi ohun ti iwọ ri si gongo ori ẹmi rẹ ki o si mã lo o bi oṣuwọn ti iwọ yio mã fi wọn iwa rẹ wò niwọnigbati iwọ ba mbẹ ni ori ilẹ aiye."

Bayi ni ọkunrin nã sọ, lẹhin eyi o gbe mi le ejika rẹ bi iti imã ṣe o si tun nfo lọ o gbe mi titi o fi de ori ilẹ aiye. Lẹhinnã o sọ mi kalẹ ni ejika rẹ, o fi ọwọ bà mi lori, o si nfẹ lọ. Ṣugbọn nko fẹ ki o lọ mọ, mo ti bẹrẹsi fẹran rẹ, ṣugbọn bi mo fẹ bi mo kọ̀ o ni lati fi mi silẹ ni, oju ro mi gãn nigbati o mã lọ, o si tù mi loju o ni on o tun wa mã ri mi lẹhin nã, o nfo lọ o si bẹrẹsi ki mi bi o ti nlọ o nwipe " Pẹlẹ o, ọmọ mi, pẹlẹ o, ki baba rẹ, ati iya rẹ pẹlu, si ki awọn aburo rẹ ati pãpã awọn ọmọ iya rẹ wọnni ti nwọn duro le gongo orí ẹmi rẹ."

Bi o ti nki mi bẽni emi nã ndahun, mo dahun titi o fi di pe mo ji, ala nã si dabi oju aiye loju mi.

Nko gburo ọkunrin nã loju ala mọ fun ọpọlọpọ igba





mo si bẹrẹsi rò ninu ara mi pe nigbati o ba di ọdun kẹta ng o tun ri i. Nigbati ọdun kẹta bẹrẹ mo bẹrẹsi ṣe akiyesi orun mi, mo sun titi nko la ala ri i ṣugbọn nigbati nko ronu nipa rẹ mọ ti ọdun nã nsunmọ ipari, ni oru ọjọ kẹrin mọju ojọ karun oṣu kẹjọ mo tun la ala, mo ri i. Mo ri i bi mo ti ṣe mã nri i, ko yi aṣọ rẹ pada rara bẽni ko si dagba si i loju mi. O ki mi dãdã o si tun gbe mi le ejika o nfo lọ. Nigbati a fo titi ti a kọja aiye tan ti a si fo jina ju bi a ti mã nfo ri a ja si ibikan ti o dabi ori ilẹ gãn o si gbe mi sọkalẹ ṣugbọn ibiti a de nã dara tobẽ ti mo fẹrẹ má le pe e ni ilẹ rara, onirũru òdòdó olõrun didun ni mo ri nibẹ, ṣugbọn ọna ti nwọn ṣe si ãrin awọn ododo nã gõlu ni nwọn fi tẹ ilẹ ibẹ lọ on ni nwọn si fi ṣe ọsọ yi gbogbo ibẹ ka bi nwọn ba mã gbin ododo sinu ikoko, ikoko gõlu ni nwọn mã gbin i si, ohun elo gbogbo ti mo ri nibẹ ṣa, ko si eyiti ki iṣe ti gõlu ninu wọn. Ni iwaju mi mo ri ile nla kan ti o dara tobẽ ti ko si ãfin ọba aiye ti enia le fi we e. Ibẹ ni ọkunrin nã mu mi ti a lọ ti a tẹ oju ọna gõlu nì lọ.

Nigbati a de inu ile nã awọn ohun ti mo ri nibẹ niyelori tobẽ ti kò ṣẽ sọ fun ni, nitori gbogbo aga ti o wà nibẹ ti diamondi ni, bẽni gõlu ni nwọn lo bi òwú ti nwọn fi hun aṣọ ti nwọn tẹ si isalẹ ile nã ati timutimu ori aga. Nigbati mo de ibẹ ẹru ba mi lati gbe ẹsẹ mi le ilẹ ṣugbọn ẹniti o mu mi lọ kò bikita rara o nrin ori aṣọ gõlu nã lọ o si di mi mu o ni ki ntẹle on, bẽ ni o si bẹrẹsi fà mi lọ titi o fi mu mi wọ iyãra kan ninu ile nã lọ.

Nigbati a de ọhun o ṣi gbogbo ferese iyãra nã silẹ o si mu mi lọ si ibi ọkan ninu wọn o ni ki nyọju si ita mo si ṣe bẽ, mo si nwo isalẹ o si dabi ẹnipe o sunmọ mi dãdã. Ibiti mo ti nṣe eyi ọkunrin nã fi mi silẹ o

lọ; ṣugbọn ki o to lọ o wi fun mi pe ki nṣakiyesi ohun ti mo ba ri dãdã ati wipe on npada bọ laipẹ, emi nã si tẹju mọ isalẹ mo nwo nkan ti yio ṣẹlẹ.

Nkan ti mo kọ ṣe akiyesi ni yi, mo ri ọna titobi kan, o tobi to ọna ti mọto mẹrin ti le fi ẹgbẹ k'ẹgbẹ ki nwọn mã lọ. Ṣugbọn ogiri kekere kan wà ti o nipọn pupọ ti ko si ga ju ẹsẹ bata kan lọ, o pin ọna nla yi ni iya si meji ọgbọ̃gba. Lẹhin eleyi mo wa ri ọkunrin kan ọlọla bayi ti o wọ aṣọ olowo iyebiye, bata olowo iyebiye, ti o si tun de fila olowo iyebiye, o jade lati inu ile kan ti o dara pupọ ti o dabi ãfin ọba, ogunlọgọ enia ni o tẹle ọkunrin yi, awọn diẹ wọ aṣọ ti o dara bĩ tirẹ̀ ṣugbọn awọn miran tẹle e bi iranṣẹ ni. Mo si ri i o yà si apakan ọna nla nì, gbogbo enia si nki i lọtun losi bi o ti nlọ.

Lẹhin eyi mo ri ọkunrin kan bayi ti o wọ aṣọ funfun ṣokoto ati ẹwu ti o nbọ ni on nkan o nba ọna kannã lọ on yà si apa ọtun, ogiri kekere ãrin ọna l'o si pin awọn mejeji ni iya.

Ko pẹ pupọ ti gbogbo wọn ti nrin lọ afi igbati mo ri ọkunrin ọlọla nì ati awọn ero ẹhin rẹ̀ ti nwọn yà si ọdọ ọkunrin alaṣọ funfun nì ti nwọn di i mu ti nwọn si tu epo Oyinbo ti a fi ntan atupa si i lara. Ọkunrin yi ko si sọrọ titi nwọn fi nṣe bẹ̃. Nigbati nwọn ṣe bẹ̃ tan nwọn ṣa iṣana si i lara ina nã si njo, aiya mi ja mo ṣebi yio ku ni ṣugbọn bi ina ti njo aṣọ ọkunrin yi aṣọ nã ko jona rara, ina jo bùlàbùlà o tun ku ni. Nigbati ina yi ku dipo ki ẽdu tilẹ wà lara aṣọ rara ṣe ni aṣọ nã yipada ti o tubọ funfun si i, o dabi ẹnipe nwọn ṣẹṣẹ mu u ti ile alagbafọ ti o mọ iṣẹ ni.

Ko pẹ pupọ lẹhin eyi ti mo ri ti ile ti ọkunrin ọlọla nì ti jade ti mo wipe o dabi ãfin dede rọ kẹ̀kẹ̀ afi were ti o wo lulẹ ṣugbọn ọkunrin ọlọla nã ati awọn ero ẹhin





rẹ̀ ti rin jinna tobẽ̩ ti nwọn ko tilẹ gbọ pe ile nã wo.

Lẹhin eyi mo tun ri awọn ero ẹhin ọlọla nã ati on pãpã bẹrẹsi jo ti onilu kan nlu ilu fun wọn. Bi nwọn ti njo ni nwọn nyẹ ọkunrin ọlọla yi si ti nwọn ndọbalẹ fun u ti nwọn nfi owo lẹ ẹ niwaju, bayi ni nwọn njo titi nwọn fi de ibi odo kan, ṣugbọn eyiti o ya mi lẹnu ju ni pe bi nwọn ti jo de eti odo yi airotẹlẹ ni awọn ero ẹhin ọlọla nã gbe e ti nwọn ju u si inu omi ti o si bẹrẹsi wẹ̀ titi o fi tun wa aye goke, gbogbo aṣọ rẹ̀ tutu patapata. Bi o ti goke tan ni o ki ire mọlẹ o bẹrẹsi salọ si ibi ile ti o ti jade ni ireti ati ba lọ mu aṣọ miran ni ile ṣugbọn nigbati o de ibẹ ko ba ile mọ, ile ti wo bẽ̩ni awọn ọkunrin wọnni tun nle e kiri, Nigbati o ṣe nwọn ba a, nwọn si mu u nwọn dè é, nwọn so okuta kan mọ ọ ni ẹ̀gbẹ́ nwọn so ọkan mọ ọ ni ọrun nwọn si so ọkan mọ ọ ni ẹsẹ nwọn gbe e o di ibi odo nì, nigbati nwọn de ọhun, ọkunrin nã kigbe nla, o sọkun kikoro, o bẹ̀ wọn titi ṣugbọn nwọn ko tilẹ wọ o loju rara, nwọn ju u si inu odo nã o si ri si isalẹ, ãnu ọlọla nã si ṣe mi lọpọlọpọ.

Bi nwọn ti ṣe ọlọla nã bayi tan ni nwọn sare o di ọdọ ọkunrin keji ti o nrin lọ jẹjẹ ni tirẹ̀ nigbati mo si wo ọkunrin nã lọkankan mo ri i pe o ti wọ ẹwu miran. Ẹwu rẹ̀ jẹ ẹwu gõlu fila ori rẹ̀ si jẹ ti diamondi, bata rẹ̀ jẹ bata idẹ. Awọn ti o ti tẹle ọlọla nì de ọdọ rẹ̀ nwọn dọbalẹ, ṣugbọn dipo ki on nã ki wọn ṣe ni mo ri i ti o fa paṣan yọ ti o bẹrẹsi le wọn lọ.

Ibiti mo ri mọ ni oju ferese ni eyi, ti ẹniti o fi mi si ibẹ fi tun de ti o fi ọwọ ba mi ni ẹhin ti emi nã kọju si i.

Ọkunrin nã bẽre ohun ti mo ri emi nã si rò fun u, o bi mi bi ohun ti mo ri wọnni ba ye mi tabi bi nwọn kò ba ye mi, mo si wi fun u pe nwọn ko ye mi rara. Lẹhinnã o bẹrẹsi fi nkan gbogbo ye mi o ni:

"Iwọ ọmọ mi, apẽrẹ ni iwọ ri nì. Ibiti iwọ ri ni isalẹ lati oju ferese ko si ni ode aiye bẽni ki iṣe ilu ọrun, o wà lagbedemeji aiye on ọrun, Ẹlẹda ni o sọ ilẹ nã lọjọ̀ si ibiti o wà nì. Ọlọla ti iwọ ri ni ẹniti orukọ rẹ̀ njẹ Arekereke-ọkunrin, ki iṣe enia rara, iwin buruku ni. Abẹ Eṣu ni o ti wà tẹlẹ ri, ṣugbọn bi Eṣu ti gba orukọ ti o buru to lãrin awọn ẹda nì, Arekereke-ọkunrin tun buru ju Eṣu lọ. Tẹlẹtẹlẹ larin awọn ẹda ti ngbe ọdọ Olodumare ni on wà, ṣugbọn nitori iwa rẹ̀ ko ba ti awọn maleka mu, nitori awọn ẹda mimọ ni awọn wọnni, Arekereke-ọkunrin pãpã l'o sa kuro ni ode ọrun ti o tọ Eṣu lọ. Nigbati o de ọhun Eṣu fi i si ipo keje lãrin awọn ọmọ abẹ rẹ̀, ṣugbọn Arekereke-ọkunrin ni o le ju gbogbo ẹda lọ on ni rikiṣi rẹ̀ si pọ ju ti gbogbo awọn ọmọ ti Ẹlẹda da, o fi ọna èrú yẹ awọn aṣãju rẹ̀ ni ipo si ẹhin a mã yọ kẹlẹkẹlẹ lọ purọ mọ wọn lọdọ Eṣu ti iṣe ọba ilu Ọrun Apãdi ninu ina ileru. Bi ire bi ire Eṣu fi ọkunrin yi ṣe igba keji ara rẹ̀ ṣugbọn ko pẹ ti o de ipo yi ti o fi ko awọn ọmọ abẹ rẹ̀ mọra ti o di rikiṣi nla mọ Eṣu pãpã lati ba le Eṣu jade kuro ni ori itẹ, bi Eṣu ba jade o ku ibiti Eṣu mã lọ, ọrun rere ni nwọn ti le e wa, o fẹ ki Eṣu parẹ patapata ki on ba le jọba dipo rẹ̀ lori ina ileru. Ṣugbọn asẹhinwa asẹhinbọ, Eṣu gbọ ọrọ yi, igbẹhin rẹ̀ si ni wipe o le Arekereke-ọkunrin kuro ni ọdọ rẹ̀, on si salọ si ilu ti iwọ ri nì. Ayọ mi si wa ni loni pe igbẹhin ọkunrin nã ṣe oju rẹ.

"Nigbati Arekereke-ọkunrin de ilu ti o wà ni agbedemeji aiye on ọrun yi o tun bẹrẹsi hu iwa rẹ̀ o nṣe ibi lojojumọ. Ile rẹ̀ ti iwọ ti ri i nì, owo olowo ni o fi kọ ọ, abẹtẹlẹ rẹ̀ pọ tobẽ ti ko le ṣe ohun kan fun ẹnikẹni ni ode aiye yi afi bi o ba gba nkankan lọwọ oluwarẹ̀. Nipa bayi a mã fi awọn alaimọkan si ipo pataki, a





mã ba orukọ oloruko jẹ, a mã purọ mọ ori olori, o si ko ogunlọgọ awọn agabagebe enia si ẹhin ara rẹ̀ awọn ni iwọ ri ti nwọn ntẹle e kiri.

Ọkunrin keji ti o wọ aṣọ funfun ti iwọ ri, olododo enia ni, ṣugbọn bi Arekereke-ọkunrin ti ṣe e to bi ẹnipe ki o sọ ọ di ero ẹhin ko bọ si i fun u, dipo ki ọwọ olododo re ẹhin iwaju ni o nlọ, awọn eleke ni iya jẹ, awọn ọmọ ẹhin Arekereke-ọkunrin ko yẹ ni ẹniti a ba gbẹkẹle, bi nwọn ti nyìn i loju ara rẹ̀ ni nwọn nbu u lẹhin rẹ̀, rikiṣi ni o pa gbogbo wọn pọ ṣe ọkanṣoṣo. Ọjọ yi gãn ti nwọn ba a lọ si ode ti nwọn nyẹ ẹ si ti nwọn kọ gbiyanju ati ṣe ijamba fun olododo yi nã ni gbogbo wọn ti fi ọwọ so ọwọ pọ pe ki awọn wo ile Arekereke-ọkunrin, awọn ni nwọn ṣe ọna ti ile fi wo igbati nwọn si mọ pe ile ti wo tan ni nwọn yi oju pada si i, awọn nã ni nwọn si ri ẹhin rẹ̀. Igbati nwọn ṣe eleyini tan ni nwọn sa tọ olododo lọ iwọ nã si ri i bi onitọhun ti le wọn lọ patapata.

"Iwọ ọmọ mi, ọgbọn ni eyi fun ọ; fi i si ipamọ dãdã, õtọ ni ki o mã sọ titi ọjọ aiye rẹ fun awọn ọmọ araiye, õtọ lagbara, õtọ duro titi, eke ko ni gbongbo, eke a mã jẹki eleke tẹ, eke a mã ge eleke wẹlẹwẹlẹ, a mã gba iyi lọwọ ẹni. Bẹru iku, bẹru àrùn, bẹru wahala ode aiye, ṣugbọn maṣe bẹru ati sọ õtọ lailai; fẹran ọrẹ, fẹran iyekan, fẹran awọn ọmọ enia ni agbajọ, ṣugbọn maṣe fẹran eke lailai. Bi enia dara bi egbin, ti o ni onirũru aṣọ bi alagẹmọ, eke a tẹ ẹ de ilẹ koko, nitori enia lasan ni eleke, ẹniti o sọ eyi loni ti o sọ tọhun lọla ko jamọ nkankan lãrin ọmọ ènia, ko si le ni gbongbo rara, o yẹ ki ọmọluwabi sọrọ ki a ba a bẽ, agbọyisọyi ko ni le duro lãrin awọn enia iwaju, yio mã wa lãrin awọn ero ẹhin lailai. Eleke ọmọ ki

ini iyi lọdọ awọn àgbà, nitori bi o tilẹ nsọ õtọ bayi awọn àgbà a mã ronu wipe bọya irọ ni o npa.

"Mã lọ nisisiyi, iwọ ọmọ mi, ṣe akiyesi awọn ọrọ wọnni fi wọn si ibi pataki lọkan rẹ, nitori íṣẹ pataki wa fun ọ lati ṣe fun awọn ọmọ araiye, pẹlẹ o, o digba, ba mi ki baba rẹ, si ki iya rẹ pẹlu, ba mi ki awọn aburo rẹ, oni ni ki o ti mã ko awọn ọmọ iya rẹ lẹnu jọ, nitori ọjọ nbọ ti baba rẹ ti iwọ nwo ni ko ni si ni ode aiye mọ, ti yio ku iwọ nikanṣoṣo bi aṣãju fun awọn aburo rẹ, ẹru nla ni eyini, Olodumare yio si ba ọ ṣe oṣuka anfani ti iwọ yio fi le gbe e."

Bi ó ti wi bayi tan ó fa mi lọwọ a si jade ninu ile nã, bi a si ti de ẹnu ọna ó gbe mi, mo tilẹ kọ ṣebi ó fẹ mã gbe mi fo lọ bi ó ti ṣe gbe mi wa ni ṣugbọn ko ṣe bẹ̃ rara, gbigbe ti o gbe mi ṣe ni mo ri i ti o sọ mi si isalẹ ni ofũrufu mo si nja lọ si isalẹ, mo tilẹ ṣebi mo mã ku ni, ṣugbọn ọkunrin nã nki mi bi mo ti nlọ emi nã si ndahun, nigbati mo si fi ẹsẹ kanlẹ bayi ni mo taji.

Mo la ala yi ni oru ọjọ Satide mọju ọsẹ. Baba mi ti oko de ni Satide nã, nigbati ilẹ ọjọ ọsẹ si mọ mo lọ ki i ni iyãra rẹ, nigbati mo ki i tan mo rọ ala nã fun u. Nigbati mo rọ ọ fun u o ni ki nṣe ẹnu mi jẹjẹ wipe Olodumare fẹ lo mi ni.



## ALABAPADE ÌRÈKÉ-ONÍBÙDÓ.

Lati igbati mo ti la alạ yi nko tun ri ọkunrin nã loju ala mọ, ṣugbọn o to bi ọdun meji nisisiyi ti mo tun ri nkankan ti o jẹ mọ ọrọ ọkunrin nã, bayi ni: O jẹ aṣa mi nigbati a nwi yi wipe ki nmã gba atẹgun ni alãlẹ ni oju ọna oko kekere kan bayi ni ilu ti mo ti nṣiṣẹ.

Lọjọ ti mo nsọrọ rẹ̀ yi mọ rin ju bi mo ti mã nrin ri lọ. Niwọnigbati o si ti jẹ ọna oko ti ọpọlọpọ enia mã nlọ mo npade awọn ero oko bi mo ti nrin lọ, ṣugbọn nigbati o ṣe ti mo de ibi igi ràbàtà kan bayi, ti ko si enia niwaju ti ko si lẹhin mo ro pe ibiti mo de yi to, mo si nfẹ pada. Njẹ bi mo ti yi oju pada bayi, ki nmã lọ, ni mo dede ri ẹni nã ti o di mi l'ọrun ọwọ mu, ọwọ rẹ̀ si tutu nini. Mo ta giri mo yi oju pada werewere, nigbati mo si wo o, o jẹ arẹwa ọkunrin kan ti o wọ ẹwu àrán pupa bayi ti oju rẹ̀ si fa ni mọra. O bu si ẹrin bi o ti ri oju mi ehin rẹ̀ si funfun kinkin. Lẹhinnã o ki mi dãdã, o si ki mi bi ẹnipe o ti mọ mi tẹlẹ ri. Emi nã ki i dãdã nko si fẹ ṣe bi ẹnipe nko mọ ẹniti o jẹ ki o má ba dabi afojudi nitori pupọ ninu awọn enia ni ki ifẹ bi a ba sọ fun wọn pe a ko ranti ẹniti nwọn jẹ mọ.

Lẹhin eleyi mo kọju si ọna ile mo nlọ on nã si kọju si ọna ibẹ ṣugbọn nigbati mo ti kọ wo o loju ni mo ti wo ẹhin mọ mo si ṣebi awa nikan ni a jọ nlọ ni, afi igbati mo dede gbọ lẹhin mi ti ẹnikan ke si ọkunrin nã ti o wipe: "Ọga, ẹ ko si duro de wa mọ ni?"

Nigbati ẹni nã wi bayi ti mo wo ẹhin mo ri awọn

mẹfa ti nwọn ru ẹru nla, igbanã ni mo si tubọ wa mọ pe enia pataki ni ọkunrin nã.

Iyalẹnu l'o jẹ fun mi nigbati ọkan ninu awọn alãru nì bẽre lọwọ rẹ̀ ti o ni: " Ẹ ko bi ọkunrin yi wo bọya o le mọ ile ibiti a nlọ ? " Ti o si dahun ti o wipe " Ọkunrin yi pãpã ni ẹniti a ntọ lọ "—eyini ni emi. Alãru keji si tun na ika rẹ̀ si mi o ni: " Ọkunrin yi ? " Ọkunrin nã si tun fesi o ni " Hãn on ni." Ọkunrin nã wa tun wo mi loju o ni: " Ṣe iwọ ni ọmọ Akintunde ti iṣe ọmọ Beyioku ? " Emi nã si dahun mo ni, " Emi ni." Lẹhin eyi o lu mi ni ejika o ni, " Mã nṣo ni 'le rẹ ile rẹ ni mo nlọ." Lẹhinnã wayi ni mo wa bi i lẽre mo ni " Ẹ jọwọ ẹ maṣe wipe mo ṣe afojudi o, nko mà ranti yin mọ." Ṣugbọn o bu si ẹrin o ni on ko iti ifẹ sọ ẹniti on jẹ fun mi ati pe igbati a ba de ile mi ni on o sọ. Awa mejeji ba kọju si ọna a nlọ, bẽni o si wa jẹ pe emi ti mo gba atẹgun lọ ni temi di ẹniti o ni alejo kitikiti.

Nigbati mo de ile o ya awọn ara ile lẹnu wipe alejo ni mo gbe ti ọna oko bọ. Ṣugbọn ko pẹ ti mo de ile ti mo pe iyawo mi si ẹhinkunle ti mo rọra yọ kẹlẹkẹlẹ sọ fun u bi mo ti ṣe ri ọkunrin nã ati awọn alãru rẹ̀. Iyawo mi si bi mi o ni " Ewo ni ṣiṣe ? " Mo ni, " Ko ni ṣiṣe kò l'aiṣe ki ẹ yara mã wa nkan alejo ni." Mo bẽre bi ọbẹ̀ ba wà ni ile o wi fun mi pe ọbẹ̀ wà ati wipe ọsan ọjọ nã ni on ṣẹ̀ṣẹ̀ se ọbẹ ata kan, ẹja ni on si fi se e.

Ko pẹ pupọ ti ilẹ fi ṣu, nitori oju alẹ ni mo gba atẹgun lọ, nigbati o si mã to dẽdẽ agogo meje onjẹ ti ṣetan. A pe alejo nã lọ si ibi ile onjẹ wa a si jọ njẹun lori tabili wa. A gbe onjẹ ti awọn alãru fun wọn lọtọ̀.

Nigbati mo ti ti ọna oko de ni mo ti ranṣẹ ẹmu ki o si to di wipe a jẹun ni nwọn ti gbe ẹmu nã de mo si gbe e si inu iyãra mi. Igbati a jẹun tan mo ni ki





ọmọ mi gbe ẹmu si ode a si bu ẹmu nã fun awọn alejo wa ògidì ni ẹmu nã, nwọn gbadun rẹ̀ dãdã.

Lẹhin eyi mo gbe aga si iwaju ile mi awa mejeji si joko, oṣupa dabi ọsan, oju ọrun mọ kedere.

Bi a ti joko yi a bẹrẹsi sọrọ a sọrọ bi oṣupa ti nran to lọjọ nã a tun sọrọ bi akoko nã ti jẹ akoko ẽrun ti ohun gbogbo gbẹ patapata, eweko inu igbo gbẹ, ilẹ gbẹ, awọn odo kekere si gbẹ ; oungbẹ ngbẹ enia oungbẹ ngbẹ ẹranko. A si tun sọrọ bi akoko ẽrun ti jẹ akoko ibẹru fun ọpọlọpọ enia, ti o jẹ pe aisan tete ntan kalẹ nitori eruku ki ijẹki enia simi, ti o jẹ pe bi akoko ẽrun ti jẹ akoko buruku o tun jẹ akoko rere lọna kan, akoko ti inu igbo nmọlẹ kedere, ti ara ọmọ enia nya gágá ti ilẹ ki itutu bi akoko ojo ti o si jẹ akoko pataki fun awọn alagbafọ ti nwọn mã nri õrun sa aṣọ wọn ; ti ko si wipe ki a fẹ ṣe nkan pataki ki ojo di ni lọwọ, ki a fẹ lọ si ibikan ki igi wo di oju ọna, ki a wọ ṣokoto gigun ki àbàtà ta si ni ni sòkòtò, akoko ẽrun yatọ pupọ si akoko ojo nipa nkan bawọnni. Emi ati ọrẹ mi wo oke a si ri awọn irawọ ti o yọ gbogbo, a sọrọ nipa irawọ wọnni, a ronu bi ọgbọn Olodumare ti to, bi ojo rọ̀ bi ojo ko rọ ina ti Olodumare tan si oju ọrun ki iku, Ẹlẹda ki iwa epo atupa kakiri ile onile, atupa Olodumare ki ifọ, epo atupa Rẹ̀ ki itan, ki isi idanu, bẽni afẹ̃fẹ ko lagbara lori ina ti Olodumare tan si oju ọrun. Gbogbo nkan wọnyi ni a bẹrẹsi sọrọ rẹ̀ nigbati ọrẹ mi yi wipe ki njẹki a wọle ati wipe on ni ọrọ kan lati ba mi sọ. Emi nã si gba bẽ, mo pe awọn ọmọ ọdọ mi ṣugbọn nko gburo wọn, bi mo si ti nṣe eyini ọmọ mi ọkunrin ti o ti wà lọdọ mi nigbati emi ati ọkunrin nã ti nsọrọ wipe ki nfi awọn ọmọ ọdọ silẹ, wipe nwọn ṣire ba ibikan lọ ni tiwọn ni, were on ati aburo rẹ̀ bẹrẹsi ko aga wọle emi ati ọkunrin nã si bọ si iyãra

mi ti mo ti mã nkawe, mo gbe aga fun u, o fi idi le aga, emi nã gbe aga kan mo fi idi le e, mo gbe ẹsẹ osi mi le ti ọtun mo fi igbọnwọ osi ti tabili, mo fi ọwọ osi ti pari ẹrẹkẹ, mo wi fun u ki o mã ba ọrọ rẹ̀ lọ. Ṣugbọn ki ọkunrin nã to bẹrẹsi sọrọ o wi fun mi pe ki nko nkan ti ng o fi kọwe silẹ ati wipe on nfẹ ki nkọ nkan ti on o sọ fun mi silẹ. Emi nã si ṣe bi o ti wi, nigbati mo ṣe eyi o bẹrẹsi ọrọ rẹ̀ o ni:

"Iwọ ọmọkunrin, a ran mi si ọ loni lati wa ba ọ sọrọ ni, a ran mi si ọ ki iwọ ki o ba le fi igbesi aiye mi han si awọn ọmọ araiye; a ran mi si ọ gẹgẹ bi ẹniti o kù diẹ ki o ṣubu ṣugbọn ti Olodumare gbe dide; kede mi fun awọn ọmọde; kede mi fun awọn agbalagba; fọnrere mi fun awọn ọmọ alade, fọn ọ fun awọn ọba ti o wọ ẹwu ilẹkẹ, fọn ọ fun awọn alaini; fọn ọ fun awọn ti o wà ni ibulẹ aiṣan, si fọn ọ fun awọn otoṣi ati fun awọn ti ko ri nkan ṣe nkan.

"Wo mi dãdã, wo mi ki o tun mi wo, wo mi ki o ba mọ ẹniti emi nṣe. Emi ni ẹniti oju rẹ̀ ri abami nkan sẹhin, emi ni ẹniti orukọ rẹ̀ njẹ Ìrèké-oníbùdó ti o ti rin jakejado ori ilẹ aiye, mo ti rekọja omi okun ti o yi aiye po, mo ti rekọja omi ọsa ti o wà ni ọpọlọpọ orilẹ ede, mo ti de aginju nibiti igbo dudu mirinmirin, mo si ti de ãrin awọn kiniun ati amọtẹkun, ikõko ati ìmàdò, ẹkun ati àgbàlàngbó, ọka ati erè, lekeleke ati àdán, iroko ati ọganwo, ati ologoṣẹ ti iru rẹ̀ ri gbõrọ.

"Emi, Ìrèké-oníbùdó, ni iwọ ri ni ijọsi nigbati iwọ wà ni kekere, ti awọn ẹda rugudu wọnni gbe ọ lọ si ọdọ ọkunrin alaṣọ funfun. Emi ni ọkunrin alakisa nã ti o duro nigbati abami ẹda nã nba ọ sọrọ, ti o nsọ bi igbesi aiye rẹ yio ti ri fun ọ."

O ya mi lẹnu nigbati ọkunrin nã wipe on ni ọkunrin alakisa ti mo ri nigbati mo wà ni kekere nitori o ti yipada pupọ loju mi ṣugbọn bi o ti ṣe yipada tobẹ̃ ya mi lẹnu ṣugbọn nigbati mo wo o dãdã lõtọ mo ri i wipe on ni ṣugbọn ko dagba si i, bi ẹnipe o tubọ nkere si i l'o ri loju mi. Nigbati mo wo o dãdã ti mo ri i pe on ni tan mo di i mu on nã si di mi mu pẹlu a ki ara wa dãdã. Lẹhinnã mo tubọ sun aga mi mọ tabili mi mo mura silẹ fun iwe kikọ mo si wi fun u pe ki o mã ba ọrọ rẹ̀ lọ, on nã si bẹrẹsi sọrọ o ni:

"Iwọ ọrẹ mi, ki nto mã sọ nkan ti ng o sọ mo ni lati kọ dupẹ lọwọ rẹ fun gbogbo itọju mi ti o ti ṣe sẹhin loni, biotilẹjẹpe o ko mọ mi, sibẹ o ṣe itọju mi de gongo, o gba mi tọwọtẹsẹ, o kẹ mi, o gẹ̀ mi, o tọju awọn enia mi, o ko tilẹ roju ati nawọ fun mi rara, ó ya mi lẹnu, ko si tun ya mi lẹnu nã, nitori wipe ati ọjọ ti mo ti ri ọ ni igba ewe rẹ ni mo ti mọ iru ẹniti iwọ yio jẹ. Mo dupẹ pupọ lọwọ rẹ, orisun ibukun rẹ ki yio gbẹ, ibiti o fi nṣe ọmọ enia ko ni bajẹ, Olodumare kò ni gba anfani rẹ lọwọ rẹ.

"Nko ni sọ itan igbesi aiye mi fun ọ loni, nitori ilẹ ti ṣu, nigbati o ba di owurọ ọla ng o mã sọ eyini fun ọ. Ṣugbọn ki a to sun lalẹ yi ng o sọ itan kan fun ọ ng o si kọ ọ ni ọgbọn pataki kan.

"Bi enia kan ba fi iya jẹ ọ ni ode aiye yi jọwọ mã ronu dãdã ki o to wipe o nfẹ gbọn iya nã nu, iya miran wà ti o le jẹ ni ti enia ko ni tilẹ gbọn nu rara nitori ẹniti ko lagbara ati gbọn iya nu ti o nfẹ gbọn ọ nù oluwarẹ yio tubọ mã jiya kun iya ni. Awọn omugọ enia kun inu aiye de ẹnu bamubamu, ẹniti o wà ni ile iwe ti o ni olukọ on fi iya jẹ on ti o si npa ero ati gbọn iya nã nu, o ko mọ pe eleyini ni ìlábùrù baba ọbọ. Ọmọ ọdọ a mã gbọn ju oluwa rẹ̀? Bakannã ni pẹlu, awọn ẹlomiran a wà ni ibi iṣẹ, ọga wọn a fi iya jẹ wọn ṣugbọn dipo ki nwọn rọra mã ba iṣẹ wọn

lọ ni tiwọn nwọn a wa ọrun kì nwọn a ni awọn nwa ifarapa ọga awọn, awọn wèrè, awọn dọ̀ngíṣọlá gbogbo, dipo ki nwọn rọju ki nwọn fi ara da iṣoro titi awọn nã a fi di ọga fun awọn ẹlomiran nwọn a mã ṣe ileri ohun ti awọn o ṣe. Nwọn ti gbagbe pe ki enia to le ri anfani nla oluwarẹ ni lati jiya nla, ki enia to le de ipo nla oluwarẹ ni lati mu sũru nla, ọmọ ọdọ ko le gbọn ju oluwarẹ lọ.

"Mo si tun fẹ ki o mọ pe awọn ẹlomiran wa ti nwọn duro gẹgẹ bi ẹgun oṣuṣu ati atẹlẹsẹ si ãrin awọn ọmọ enia awọn ti ẹri ọkan wọn ti ku ti o jẹ́ pe Olodumare ni o mọ ọna ti on le fi ji ẹri ọkan wọn dide, bi iru awọn wọnni ba ṣe ọ ni ibi kan ṣe ni ki o yara mã salọ, nitori bi o ba wipe o fẹ gbẹṣan nwọn o ṣe ọ ni meji, bi o ba duro nwọn o ṣe ọ ju meji lọ. Ati pãpã, awọn wọnni ti mọ ọna ibi tobẹ̃ ti o fi jẹ wipe ati mu wọn ṣoro gidigidi. Bi enia kan ba jẹ oniwa lile, ti o nṣe ipanle kiri, maṣe fi ara we e lailai, nitori bi iwa ìpáǹlè ko ba si ni ẹda rẹ, ẽkanṣọṣọ ti iwọ ba ṣe tirẹ ni ọwọ awọn alagbara yio tẹ ọ ti nwọn yio fi iya jẹ ọ dãdã.

"Awọn ọmọde nilati ṣọra wọn dãdã, ki nwọn ṣọra wọn nipa ẹgbẹkẹgbẹ, nitori ogunlọgọ awọn ọmọdé l'o ti fi iya jẹ ara wọn nipa wipe ki nwọn mã ba ọmọ buruku kiri, igbati o ba ṣe ọmọ buruku a bẹrẹsi fi iya jẹ wọn, igbati awọn nã ba si ni ki awọn fi iya jẹ ẹ pada nwọn a ṣe ara wọn l'éṣe.

"Ode aiye yi si tun dara lọna kan, o dara wipe iba enia l'o wà nibẹ ti ko ni ọga niwaju ati pãpã awọn ti o tilẹ dabi ẹnipe nwọn ko ni ọga wọnni, sibẹ nã Olodumare mbẹ niwaju wọn. Bi ẹnikan ba fi nkan ṣe ni ti o bọ si irẹjẹ ti o si jẹ pe bi oluwarẹ ko ba kọ̀ yio mu oluwarẹ ni ọbọ, o san pupọ ki a fi ẹjọ eleyini sùn ju wipe ki a mã wa ọna ati gbẹsan ki o si wa dabi





ẹnipe oluwarẹ̀ nle aṣiwere kiri ; ẹniti o nlepa aṣiwere ati on ati aṣiwere nã ni ọkannã. Ọrọ yi a mã ko iya jẹ ọmọ ile iwe miran tabi awọn ọmọ imọle ti nwọn nkọ Kewu, nigbati ẹnikan ba lu wọn dipo ki nwọn lọ fi ẹjọ oluwarẹ̀ sun ọga wọn awọn nã a lu u pada, aseẹhinwa aseẹhinbọ awọn mejeji a bẹrẹsi jà, nwọn a ko wọn lọ si iwaju ọga onitọhun a da awọn mejeji ni ẹbi, ọrọ a wa di pe ki a mã fi iya jẹ wọn, bọya nwọn a fun wọn ni iṣẹ ṣe, bọya nwọn a wipe nwọn ko gbọdọ jade lọ ṣire nigbati ẹgbẹ wọn ba jade bọya ọrọ wọn a mu paṣan lọwọ, a di pe ki nwọn ko paṣan bo wọn, ki nwọn mã sọkun, ki omi mã bọ loju, ki ikun mã ti imu yọ, ki nwọn fẹ ehin si ita, ki nwọn ba gbogbo ẹnu jẹ, ki nwọn mã fi ọwọ ra ibadi, ki idi wọn dide, ki nwọn fi ilẹkẹ buruku si ibadi lairotẹlẹ, ki nwọn ṣẹṣẹ wa mã kigbe wipe 'Ẹ dakun Sà, ẹ dariji mi Sà, nkò ni ṣe bẹ̃ mọ lailai, etc.'

"Bakannã si ni lãrin awọn agbalagba, iwa buruku pọ lọwọ awọn ẹlomiran, bi nwọn ba ti ni enia sinu nwọn a mã lepa rẹ̀ lati ori kòtò bọ si ori gegele, igbamiran wà ti o jẹ wipe bi enia ba ni ki on gbẹsan iya ti ẹlomiran fi jẹ on o le ku si ibiti o ti ngbẹsan. Bi ẹjọ enia ba jare ni iṣãju o le tun pada wa jẹbi. Jẹki nsọ itan kan fun ọ iwọ ọrẹ mi, itan nã gùn diẹ ṣugbọn o yẹ ki a fi pari ọrọ wa alẹ yi.

"Ẹranko kan wà ni aiye atijọ oruko rẹ̀ a mã jẹ Ologbo-ijakadi, o jẹ ẹranko lile alarekereke si ni, ẹranko nã fi ara jọ kọlọkọlọ pupọ, ṣugbọn o ni igba lẹhin bi ti ijapa. Ẹranko ti a nwi yi ko lagbara rara, bi ko si ti lagbara yi nã gbogbo awọn ẹranko ni o mã nsa fun u nitori agabagebe rẹ̀ si ni. Bi ó ba ti ri ẹranko kan a mã ba a ṣire a si ti ipa bẹ̃ ṣire nã lọ si ibiti kiniun wà, igbati kiniun ba yọ lati inu iho on a gun igi lọ, nitori

o le gun igi, igbati on ba sa gun igi lọ a ku ẹranko keji silẹ, kiniun a si pa eleyini jẹ.

" Nigbati o ṣe, ẹkùn bẹrẹsi ba ologbo-ijakadi rin, nwọn nba ara wọn wọle, nwọn nba ara wọn jade. Bi ire bi ire ọwọ wọn nwọ ọwọ ẹsẹ wọn nwọ ẹsẹ awọn ẹranko gbogbo si bẹrẹsi ṣe akiyesi wọn.

" Nigbati iyawo ẹkun lọ si ode ni ijọ kan o gbọ nibiti awọn ẹranko ti nsọrọ ọkọ rẹ ni aidara o si pinnu pe on o wa ọna ati pin ọkọ on ati ologbo-ijakadi ni iya. Nigbati o de ile o pe ọkọ rẹ si ibi ipamọ kan o si ba a sọrọ nipa ọran nã o ni :

" 'Bãle mi, olõla ijù, ẹ sunmọ 'hin dãdã, ọrọ kan ni mo ri ti mo ni ba yin sọ. Kini ti ẹnyin ologbo-ijakadi ti jẹ ? Kil'o ti jẹ ? On ki igbe ile rẹ ni ? Tabi ọran ni ! Ẹ mã ṣe ẹgbẹ rẹ ni dan ? Tabi ewo ni gulegule ti o nṣe tẹle yin kiri, ẹ lọ yàgò fun u o, ẹ lọ yago fun ologbo-ijakadi o, bi awọn ẹranko ti nsọrọ yin ko dara rara, nitori àgbà ni ẹ nda yi, enia kò mà lè jẹki ọmọde kan wa ri on fin o. Bi mo ti nsọrọ yi ọran nã ndun mi gãn ni, nitori bi mo ti ngbọ ọ ko dara rara, nko gbọdọ ri ẹsẹ ologbo-ijakadi ni ile yi mọ'

" Bayi ni iyawo ẹkun wi fun u ṣugbọn ẹranko ko ni ṣai ṣe ẹranko, dipo ki ẹkun gba ọrọ yi yẹ'wo o bẹrẹsi ba iyawo rẹ ja, o ge iyawo ni eti jẹ, iyawo ge on nã ni imu jẹ, nwọn bẹrẹsi ba ara wọn jà, nwọn ba ile tiwọn jẹ nitori ẹni ẹlẹni. Iyawo ẹkun loyun nigbanã nigbati o si to akoko ati bimọ, ọmọ rẹ ya abuke. Ọmọ nã ni o ṣe ikeje ninu awọn ọmọ ẹkun lakoko nã.

" Igbati iyawo ẹkun ti ba ọkọ rẹ sọrọ nipa ologbo-ijakadi ti ọkọ rẹ kò ti gbọ ni on ti dakẹ ara rẹ ko tun da si ọran wọn mọ.

" Ni ọjọ kan bayi ni ologbo-ijakadi tọ ẹkun lọ ti o wipe on wa ki i, ẹkun ṣẹṣẹ pa agbọnrin kan tan ni,





on ati ologbo-ijakadi ni nwọn si jọ fi agbọnrin nã jẹ tan patapata, nwọn ko tilẹ tọ le iyawo ẹkun loju, nigbati nwọn jẹun nã tan ni ologbo-ijakadi dide ti o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni :

" ' Ọrẹ mi ọ̀wọ̀n, ẹkun, igba keji kiniun, ijoye pataki ninu awọn ẹranko. Ayọ mi ni wipe mo jẹ ọrẹ rẹ, bi a ti nṣe yi inu nbi awọn ẹlomiran, bẽni irọ ni nwọn npa', ọrẹ wa ko le bajẹ lailai, ọrun ni Ọlọrun ti fi wa ṣe ọrẹ, o si yẹ ki a mã yọ pataki si eyi, ki inu mã bi awọn abinuku ẹni. Mo fẹran rẹ de gongo, bi o ṣe obinrin mo le fẹ ọ, bi o ko si ti jẹ obinrin yi nã nkan miran wà ti a le ṣe fun ara wa, mo fẹ ṣe nkankan fun ọ ti a o fi mã ranti ara wa lailai, nitori ọrẹ wa yi ko yẹ ki o pari lọdọ wa o yẹ ki o kan awọn ọmọ wa, nitori tiwa yi ti kuro ni ọrẹ a ti di iyekan, ibi ti a si fi nwu ara wa ki Olodumare maṣe jẹki o bajẹ. Mo fẹ lati kọ ilà si awọn ọmọ rẹ lara, ila ti mo si nfẹ kọ yi yatọ si ila ti o wà lara awọn ẹranko gbogbo, bi mo ba kọ ọ tan gbogbo awọn ẹranko inu igbo ni yio mọ pe iwọ ju awọn lọ, kiniun pãpã yio mọ pe awọn ẹranko npe on l'ọba lasan ni, iwọ gãn ni o ni nkan ọba, mo fẹ ki awọn ọmọ rẹ obinrin dara tobẽ ti yio fi jẹ pe gbogbo awọn ẹranko inu igbo ni yio fẹ lati fẹ wọn, bi kiniun fẹ bi kiniun kọ kiniun yio fẹ lati di àna rẹ, kọlọkọlọ yio mu ogunlọgọ agbebọ wa lati fi wa oju rẹ mọra, agbọnrin ko ni ṣai wa ti on ti iwo lori ṣaraṣara, bẽni ajanaku yio wa pẹlu ọwọ rẹ gbõrọ. Mo si ro lọkan mi pẹlu pe bi mo ti nwo ọran nã yi, nigbati mo ba kọ ila nã tan, iyi rẹ yio pọ tobẽ ti yio ya iwọ pãpã lẹnu. Asẹhinwa asẹhinbọ mo ro pe nkan ti ng o ṣe ni wipe ki npe gbogbo awọn ẹranko jọ ni ijọ kan, iwọ kò ni si nibẹ o, ṣugbọn nigbati mo ba pe wọn jọ tan ti mo sọ gbogbo bi nkan ti jẹ fun wọn, gbogbo wa o pa ero pọ, a o mu kiniun

kuro lori oye, iwọ yio si duro gẹgẹ bi alaga lori gbogbo wa. Nitorinã eyi ti mo ni sọ fun ọ mọ ni yi, iyoku wà lọwọ rẹ. Bi o ba fẹ, jẹki a kọ ilà fun awọn ọmọ rẹ ki anfani wọle de, bi o ba si fẹ, jẹki a fi ila kikọ silẹ ki anfani mã lọ.'

" Bayi ni ẹranko buruku yi sọ, o fi iyọ Oyinbo pa majele lara, ẹkun nã gba majele o gbe e mì o dahun o ni:

" ' Ọrẹ mi pataki, ọrẹ mi õtọ, ọrẹ mi gãn, ọrẹ mi ododo, ọrẹ mi àtàtà, ọrẹ mi pàtó, ọrẹ mi owurọ, ọrẹ mi ọsan, ọrẹ mi alẹ, ọrẹ mi aiye, ọrẹ mi ọrun, ọrẹ mi lati ori de gongo imu, ọrẹ mi lati ọrun de atẹlẹsẹ, ọrẹ ti o ju iya, ọrẹ ti o ju baba, ọrẹ ti o ju ẹgbọn, ọrẹ ti o ju aburo, ọrẹ ti o ju iyekan, ọrẹ ti o ju obinrin ẹni lọ—mo dupẹ lọwọ rẹ, mo dupẹ gidigidi, ifẹ rẹ yi sa tilẹ nya mi lẹnu ṣa, nkan rere l'o mã nwa fun mi lojojumọ aiye yi! Mo gbọ b'õ ti wi, nkan ti mo ba ni, tirẹ ni, eyiti iwọ nã ba si ni, temi ni. Kil'o tun ṣẹṣẹ nbi mi lẽre si? Dandan ni pe ki a kọ ila fun awọn ọmọ mi, bi o ba ti wipe o yẹ bẽ. Nitorina ki a mu ti pe a ko ni kọ ila kuro lọna, eto bi a o ti ṣe kọ ọ ni ki a mã ṣe. Nkan ti o ba yẹ ki nwa nipa rẹ̀ ng o wa a, nitorinã eyini ni ki o sọ fun mi, ki a si tun mura ki a da ọjọ ila kikọ nã, gbogbo ọrọ temi ko ju bẽ lọ.'

" Nigbati ẹkun pari ọrọ tirẹ̀ tan ologbo-ijakadi sọrọ tẹrintẹrin o ni ' O kare.'

" Lẹhinnã o tun nba ọrọ rẹ̀ lọ o ni ' Kini kan ṣa ti o wà nibẹ ni pe a o wa ọpọlọpọ nkan ti a o fi ṣe õgun-ikọla nã, ṣugbọn a ko si le wipe o pọ ju o, nigbati a ba wo anfani ti o wa lẹhin rẹ. O nilati lọ wa ẹgbẹta iṣu, ẹgbẹta ọgẹdẹ, ẹgbẹta agbado, ẽdẹgbẹta orogbo, ẽdẹgbẹta obi, ẽdẹgbẹta ekurọ, ojilugba ẹpa, ojilugba ẹyọ owo, ojilugba ilẹkẹ, ẹgbẹrin garawa epo, ẹgbẹrin ikoko àdí, ẹgbẹrin garawa ororo ẹ̀gúsí, ọtalelegbeje





iyẹ agbẹ, ọtalelegbeje iyẹ aluko, ọtalelegbeje ikoidẹ, pẹpẹiyẹ meje, akukọ meje, tolotolo meje, ẹiyẹle meje, malũ meje, ẹṣin meje, kẹtẹkẹtẹ meje, ewurẹ meje, aguntan meje, aja meje, iyẹ ologoṣẹ, iyẹ adaba, iyẹ lekeleke, iyẹ alapandẹdẹ, iyẹ igún, iyẹ àkàlà, ori ọka, ori ere, ori paramọlẹ, iwo agbanrere, ãke, ada, ati ọbẹ.

" ' Lẹhinnã wayi o, o ni lati wa kọ ile kekere kan si ẹba ile rẹ ni oke odò, ki ile nã ni ferese kan ati ẹnu ọna kan. Awọn nkan ti mo wipe ki o wa wọnyi ko to ṣugbọn mo ti ba ọ wa iyoku ni apo ara mi, nigbati o ba si wa nkan tirẹ tan, o nilati ko gbogbo wọn wa si ile mi. Ibẹ ni ng o ti ṣe õgun ila nã. Igbati mo ba ṣe e tan ng o gbe e wa si ile kekere ti o ti pese silẹ, emi ati awọn ọmọ rẹ mejeje yio si gbe ibẹ ni ọjọ meje ibẹ ni ng o si ti kọ ila nã.'

" Dajudaju, iwọ ọrẹ mi, nkan ti ologbo-ijakadi kà silẹ yi ko ni ṣai ya ọ lẹnu, bẽ nã l'o ya gbogbo enia lẹnu, ṣugbọn gbogbo nkan wọnni ni ẹkun wa ti o pe. Omi nla kan ni o pin ile ẹkun ni iyà si ti ologbo-ijakadi, eti ile ẹkun si ni ẹkun kọ ile kekere ti ologbo-ijakadi wi fun u si, iyãra kan ni ile nã ni o si ni ferese kan.

" Bayi ni nwọn ṣe eto nã, gbogbo wọn si da ọjọ ila kikọ.

" Ki ọjọ to pe ologbo-ijakadi ti kó pupọ ninu awọn nkan onjẹ wọnni wa si ile kekere yi, o mu ọbẹ ati ãke pẹlu. Nigbati ọjọ si to nwọn kó awọn ọmọ ẹkun mejeje wa nwọn kó wọn le ẹranko yi lọwọ. Iyawo ẹkun wi fun u ki ó má kó awọn ọmọ nã lọ ṣugbọn ko gbọ, ọrọ nã si di ija ti o fi di pe ọkọ ge aya jẹ ni ete ti aya nã lu igi mọ ọkọ ni ipakọ ti o si fi di pe awọn ọmọ ẹkun nilati lọ sare pe ajanaku ati ìmàdò ti nwọn jẹ aladugbo ki nwọn wa la ija lãrin wọn.

" Iwọ ọrẹ mi, nigbati o di ọjọ ti nwọn kọ wọ ile nã

ti nwọn pa ilẹkun de mọra tan ologbo-ijakadi kọ ila si ara ọkan ninu awọn ọmọ ẹkun o si kọ ila nã dãdã. Nigbati o di ọjọ keji o pa ọkan ninu awọn ọmọ ẹkun jẹ, ni ọjọ kẹta o tun pa omiran jẹ, ni ọjọ kẹrin o tun ṣe bẽ, o si pa gbogbo awọn ọmọ ẹkun tan ki ọjọ keje to pe o wa ku ọkan ti o kọkọ kọ ila si lara, o dakẹ ni tirẹ o jẹun o yo bamubamu.

" Nigbati o di owurọ ọjọ keje o ṣi ferese o si ri ẹkun ati iyawo rẹ ti nwọn ti duro si iwaju ibiti ferese wà de e. Nigbati o ri wọn o ki wọn dãdã ṣugbọn o w fun wọn pe ki nwọn tubọ sunmọ iwaju diẹ si i, nitor gẹgẹ bi àṣà ila kikọ bi nwọn ba sunmọ ile jù ila n yio bajẹ. O ni ki nwọn sunmọ iwaju ki on mã fi ila t on ti kọ han wọn lati oju ferese, awọn nã si ṣe bẽ.

" Lẹhin eyi o gbe ọmọ ẹkun kanṣoṣo ti o kù sok han wọn lati oju ferese, nigbati nwọn ri i nwọn yọ nwọn pariwo, ẹkun wo iyawo rẹ loju o ni, ' Iwọ buruk yi, nko wi fun ọ pe eleyi fẹran awa ! ' Ologbo-ijakad tun gbe ọmọ nã pada, lẹhin eyi o tun gbe ọkan n soke lẹkeji o ni ' Ekeji ni yi o ' ; nwọn tun yọ nwọ pariwo. O tun ṣe o gbe ọkan nã soke lẹkẹta o ni. ' Ekẹt ni yi o ' ; nwọn tun yọ nwọn patẹwọ, bẽ bẽ l'o si ṣ ti o gbe ọmọ kanṣoṣo han lẹmeje. Lẹhin eyi o wi fu ẹkun pe o nilati duro fun iṣẹju meje ki o to gbọd wọle lọ wo awọn ọmọ rẹ, on jade o pa ilẹkun de, ẹku si dupẹ lọwọ rẹ lọpọlọpọ, o fun u ni agutan kan gẹg bi ẹbun fun iṣẹ rẹ ti o ṣe. Lẹhinnã o sin i lọ si eti od nibiti yio ti wọ ọkọ lọ sile. Nigbati nwọn de eti od awọn ẹja ni o nilati tu ọkọ ologbo-ijakadi ṣugbọn bi tilẹjẹpe pupọ ninu wọn ni o fẹ lati wà a kọja, eyi o jẹ aditi ninu awọn ẹja wọnni ni ẹranko buruku n gbà gẹgẹ bi atukọ on, eleyi si ya ẹkun pãpã lẹnu.

" Nigbati ẹranko yi bọ si inu ọkọ tan o yi oju pad





si ẹkun o ki i o ni, ' O digba na, lọ wo awọn ọmọ rẹ, ohunkohun ti ó ba si de, sũru ni ki o nà si i, mo ti jẹran titi ehin nro mi, mo nlọ diẹ na ki ehin mi ba simi, ki iyawo rẹ fun mi.'

" Ọrọ nã ko kọ ye ẹkun dãdã o ni : ' Nko gbọ, tun wi i ki ngbọ, kil'o ti wi ? ' Bi o ti nwi eyi lọwọ ologbo-ijakadi wi fun aditi ẹja ki o ṣi ọkọ eyini si ṣe bẽ, ọkọ nlọ on nã si nsọrọ si ẹkun, o tun ọrọ iṣãju sọ o ni, ' Mo wipe ki o mã lọ si ile rẹ, wipe mo ti jẹ ẹran titi lọjọ meje ehin nro mi, ati wipe ṣe ni mo nlọ si ile ki ehin mi ba simi.'

" Ẹkun tun fẹsi o ni, ' Ẹran bawo ? Tun wi ki ngbọ.' Nigbati on nã si tun mã fesi ọkọ ti kuro ni eti bèbè patapata o kigbe o ni, ' Mo ni ki alakọri rẹ mã lọ 'le mo ti pa ọ lọmọ jẹ tan patapata, mo ti fọ egungun wọn tũtũ, ibadi wọn ti ṣe ọra ṣinkìn si mi lẹnu.'

" Ẹkun gbọ eleyi firifiri, o yara sare pada lọ wo inu ile, o de ibẹ o ba ọmọ kanṣoṣo o si ri egungun ni ilẹ kítikìti. O ke si iyawo rẹ, gbogbo wọn sare o di rẹirẹi si eti odo, nigbati nwọn si de eti odo ti nwọn kigbe nla si aditi ẹja ki o mã wa ologbo-ijakadi pada bọ, kò gbọ dãdã igbati o si bi ologbo-ijakadi bi nwọn ti wi, kò la ohun ti nwọn wi ye e o ni, ' Ẹkun ati iyawo rẹ wipe o ko yara wa ọkọ nã lọ to, ati wipe bi o ko ba tete wa mi goke oni ni awọn o pa ọ.' Nigbati o si di pe ẹkun nsọkun o ngbe ara yi ilẹ ti o si nkigbe nla aditi ẹja tun sọrọ o ni, ' Ọrẹ mi, ologbo-ijakadi, kil'o ṣe wọn bayi ? ' Onitọhun nã si tun fesi o ni, ' Inu nbi ẹkun ati iyawo rẹ pupọ pe ọkọ nã ko yara to nwọn si nmura nisisiyi ati wa ba ọ, nitori oni yi ni nwọn o mu ori rẹ kuro lọrun rẹ.'

" Aditi ẹja tubọ mura o nwa ọkọ kikankikan o si ngbe ologbo-ijakadi sunmọ oke odo.




Ologbo-ijakadi.

“ Nigbati o tun ṣe ti nwọn nwo bèbè niwaju ti o tubọ nsunmọ wọn ologbo-ijakadi tun sọrọ o ni, ‘Iwọ ẹja yi, ãnu rẹ nṣe mi o, jọwọ mo gbà ọ niyanju ki o tubọ tẹ ọwọ mọ ọkọ yi, ẹkùn nbọ̀, nko si fẹ ki ori rẹ sun ninu apoluku ẹkun mọju oni, nitori bi ó ba le ba ọ iku de. Bẽni ọmọ l'o bi silẹ kitikiti yi, bi ọwọ ẹkun ba si ti ba ọ ọrọ pari, o kò ju okele kan fun u, ọmọ rẹ yio si di alainibaba, iyawo rẹ yio di opo, nitorinã, jọwọ, nitori ara rẹ, maṣai tẹ ọwọ mọ kini yi o.’

“ Bayi ni ẹranko nã sọ, aditi ẹja si mura kikankikan, ọkọ nlọ gẽre, ẹkun nsọkun loke odo, iyawo ẹkun nyi gbiri, ologbo-ijakadi nrẹrin, bi awọn ẹranko wọnni si ti nsọkun to bẽni ẹja nã ntẹ ọwọ mọ iṣẹ ṣiṣẹ. Laipẹ nwọn de oke odo, ologbo-ijakadi san owo ẹja fun ẹja,





onitọhun nã gba owo o dupẹ, o mõkun lọ si isalẹ odo, o ba irinkerindo rẹ lọ.

“ Lẹhin eleyi ni ologbo-ijakadi ke si ẹkun loke odo o ni, ‘Ọrẹ mi ti mbẹ lokẹ odo, o ku rògbòdìyàn nã, ṣe ko si nkan ti iyawo rẹ fi nyi ni ilẹ gbiri ? Jọwọ gba a ni iyanju ki o mã yi lọ si apa oke o, bi o ba yi lọ si isalẹ yio yi bọ si inu omi. Mo tilẹ fẹ sọ kini kan fun ọ, ẹran awọn ọmọ rẹ mà tilẹ dun o, akọbi rẹ ni mo fi ṣe onjẹ ni ijẹta, egungun ọmọ nã si ṣebi ẹnipe o le diẹ, ṣugbọn sibẹsibẹ nã mo fọ ọ de ilẹ koko ; ọra ọmọ nã pọ pupọ gãn, ṣe l'ó nkan si mi lẹnu tókí, ṣugbọn abikẹhin rẹ ni mo gbadun ju, egungun rẹ rọra nrun si mi lẹnu ni, nko si ni gbagbe agbari ọmọ nã lailai, mo fi ehin fọ ọ dãdã. O digba diẹ na, lọjọ ti ebi ba npa mi ng o wa yẹ ile rẹ wo, bi o ko ba si ti ibi ọmọ miran dajudaju ng o ri pajẹ ninu awọn ibatan rẹ. O digba o.’

“ Nigbati o wi bayi tan o ba ile rẹ lọ, igbati ẹkun nã si duro diẹ si i loke odo on nã mu iyawo rẹ nwọn kọ ori si ile.. Ihin nã tan kalẹ lãrin awọn ẹranko, awọn ẹranko kekeke gbogbo ni nwọn nfi ẹkun ṣire si ọran nã, ṣugbọn awọn agba ẹranko ko ṣe bẹ̃, nwọn kãnu gidigidi nitori ọ̀fọ̀ ti o ṣẹ̀ ẹ. Ajanaku wa lati ki i, ikõko nã wa, kiniun si ran oniṣẹ si i. Awọn ẹranko ile pãpã iba ran aṣoju wọ̀n wa ki i, ṣugbọn nigbati nwọn gbe ọrọ nã kalẹ niwaju awọn ẹran ile ti ologbo da aba nã (ki iṣe ologbo-ijakadi o), aguntan ta ko o, o wipe ko yẹ ki awọn ranṣẹ lọ ki i, malũ si kin aguntan lẹhin, nigbati aja ti o si jẹ alaga wipe ki awọn ẹran ile wọnni gbọn ìrù bi nwọn ba ro pe o yẹ ki awọn ran aṣoju lọ, awọn ti o gbọn iru ko to nkan.

“ Igbati ẹkun ro gbogbo iya ti ologbo-ijakadi fi jẹ ẹ o pinnu lati gbẹsan. Ko pẹ pupọ nã o ri agbọnrin

kan, o pa a o si gbe e tọ ọba lọ o lọ fun u gẹgẹ bi abẹtẹlẹ, ọba nã gba a. O ro ẹjọ fun ọba nwọn si pinnu ọna ti awọn le fi ri ẹranko nã mu.

" Nwọn ni ki ọba lu agogo yi ilu ka wipe on nfẹ tun ile on ṣe ni ọjọ kan wipe ki gbogbo ẹranko wa ewe wa lati ba fi tun ile ọba ṣe ; nwọn si tun fi ofin si i wipe ẹniti ko ba gbe ewe rẹ wa yio jade kuro ninu igbo. Ọba si ti sọ fun ẹkun ki o yara tete lọ si oko nibiti nwọn o ti wa ewe nã nitori ìbi kanṣoṣo ni ewe yi wà ninu igbo.

" Ologbo-ijakadi gbọ ọrọ yi o si mọ lọkan rẹ pe tori ti on ni nwọn ṣe pa ero eke bẽ on nã si ronu ọna ati yọ. Nigbati o di ãrin ọganjọ o mu iyawo rẹ lẹhin nwọn lọ si ibiti ewe nã wà o si wa ewe tirẹ o mu okùn o fi fun iyawo rẹ on nã bọ si inu ewe o ni ki iyawo on ri i pe ewe bo on patapata, iyawo ri i bẽ, lẹhinnã o wi fun iyawo rẹ ki o di ewe nã dãdã ki o di on mọ inu ewe ki o si fun on ni okun danindanin, iyawo yi ṣe bẽ, o di bãle rẹ mọ inu ewe, o fun u ni okùn tobẽ ti ẹnikẹni ko le mọ pe ẹnikan wà ninu rẹ, ẹniti o ba wo o yio ṣebi ewe lasan ni.

" Ologbo-ijakadi mọ pe nitori ti on ẹkun ni yio kọ tete de oko, nigbati iyawo rẹ si ti di i dãdã tan ni o ti wi fun u ki o mã lọ si ile o ku on nikan ninu ewe lọhun o si sunlọ.

" Ko pẹ nã ti ologbo-ijakadi ji ti o gbọ ohun ẹkun nitori ẹkun l'o ṣãju gbogbo awọn ẹranko de, nigbati o si de o wo ilẹ o wo agbegbe ko ri ẹnikan o si sọrọ soke o ni, ' Alakọri ọmọ nã ko iti ide, ng o kuku duro ti ewe ti eleyi di silẹ yi, nko ni wa ewe temi mọ ki nba ri aye mã sọ ọ nitori nigbati awọn ẹranko ba tubọ npọ si i nko ni le ri i, bi ẹniti o ni ewe yi ba ri mi gbangba bayi pe mo duro ti ewe on ati le mi kuro nibẹ





yio jẹ iṣoro, emi, ẹkùn, ògìdán, olõla ijù, akọmọlailabẹ, ko si ẹniti o to fi oju di mi lãrin awọn ẹranko.'

" Bayi ni o ṣe ti o duro titi ilẹ fi mọ ti gbogbo awọn ẹranko fi de tan ti nwọn si wa ewe tiwọn ti nwọn gbe e tọ ọba lọ.

" Nigbati o ku ẹkun nikanṣoṣo ti gbogbo awọn ẹranko ti lọ tan ti ko ri ologbo-ijakadi o pòṣé o si gbe ewe tị o wà ni ilẹ le ori laimọ pe ọta ọn ni on ngbe lọ. Nigbati o rin diẹ ologbo-ijakadi fa ẹkun ni irun ori ẹkun kò si mọ nkankan o ni, ' Ewe yi mà lè ta enia lori o.' Igbati o tun ṣe, ologbo-ijakadi tu itọ le e lori, ẹkun ni, ' Omi ewe yi mà tilẹ pọ o ' Ologbo-ijakadi sa nṣe bi o ti fẹ lori ẹkun, onitọhun di alãru fun ọta rẹ, ó ngbe e lọ. Bayi ni nwọn ṣe titi nwọn fi de ile ọba, nigbati ọba si ri ẹkun ti o bi i bi ọhun ti ri, ibanujẹ ni onitọhun fi da a lohun pe nkan nã ko bọ si i.

" Igbati ẹranko nã mọ pe ẹkun ti kuro ni ãfin o rọra jade ninu ewe nã o si tun u dì dãdã o wọle tọ ọba lọ o ni : ' Kabiyesi, mo ti gbe ẹru ewe temi de, nko si ru iru ẹrù bẽ ri, tifẹtifẹ ni mo fi ru u ṣugbọn o wọ mi lọrun tobẽ ti nko fi le ba awọn ẹgbẹ mi, nitori mo fẹran yin gãn ni, ẹnyin ni baba wa, ẹnyin ni baba agbalagba, ẹnyin ni baba wa, ẹnyin ni baba ajanaku, ẹnyin ni baba wa, ẹnyin ni baba ìmàdò, ẹnyin ni baba wa, ẹnyin ni baba agbọnrin, ẹnyin ni baba wa, ẹnyin ni baba kọlọkọlọ, ẹnyin ni baba wa ; ẹnyin ni baba ewurẹ, ẹnyin ni baba wa ; ẹnyin ni baba aguntan, ẹnyin ni baba wa ; ẹnyin ni baba ẹiyẹle, ẹnyin ni baba wa ; ẹnyin ni baba adaba, ẹnyin ni baba wa ; ẹnyin ni baba òjòlá, ẹnyin ni baba wa ; ẹnyin ni baba agbebọ, ẹnyin ni baba wa ; ẹnyin ni baba enia, ẹnyin ni baba wa ; ẹnyin ni baba enia, ẹnyin ni baba wa ; ẹnyin ni baba enia, ẹnyin ni baba wa.

"Bayi ni ologbo-ijakadi sọrọ niwaju ọba, ibiti o si ti nwipe 'Ẹnyin ni baba wa' bayi, ọba pāpā tilẹ ti gbagbe ohun ti on iba ṣe, o ki i pe o ku abọ ni.

"Iwọ ọrẹ mi, alailānu ẹranko gbã ni ologbo-ijakadi, igbati o de ile ko dakẹ bẽ, igbati o di owurọ ọjọ keji o lọ si oke odo, o ke si ẹkun ni odi keji o ni:

"'Ọrẹ mi, o ku owurọ yi o, o mà si ku ẹru àná, ṣe ọrun kò dùn ọ o?' Ẹkun nã dahun o ni, 'Tani alakọri rẹ nsọrọ si? Mo sẹbi ori rẹ mã tì ọ ki o wa lana ni, ana nã ni iwọ iba ti ri aiye mọ.' Nigbati o wi bayi ologbo-ijakadi bu sẹ́rin, o rẹrin, o rẹrin titi o ni: 'Tani kò wa? Tani kò wa? Mo wa iwọ ni kò mọ o, emi ti mo ti mọ—ọ ti ki iṣe oni, mo ṣai mọ pe tori mi ni ọba ṣe ran gbogbo wa l'oko?—Gbọ, emi ni mo wà ninu ewe ti o gbe bọ̀, emi l'o gbe tewetewe, iwọ ni alāru mi, iwọ l'o gbe mi de 'le, igbati o kù diẹ ki o kọja odo kekere kan o gbagbe ti o wipe ewe nta ọ lori? Ori kò dede ta ọ emi ni mo fà ọ ni irun; igbati mo si tu itọ le ọ lori o wipe ewe tutu, igbati o si de ile tan ti iwọ ati ọba sọrọ titi ti o lọ emi nã jade ninu ewe mo lọ ki ọba.'

"Ọrọ yi dun ẹkun tobẽ ti o fi jẹ wipe nigbati ó de ile ko le jẹun, igbati iyawo rẹ si bi i lẽre pe ki o sọ fun on bi ọran nã ti ri o ni, 'Aní emi ni mo gbe ologbo-ijakadi de 'le lana.' Iyawo rẹ dahun o ni 'Gbe tani de 'le?' O ni, 'Gbe ologbo-ijakadi de 'le ni.' Iyawo rẹ tun dahun o ni, 'Bawo?' On nã si tun fesi o ni: 'Àṣé ewe ti mo gbe, ti mo gbe ti oko wa fun ọba lana, ologbo-ijakadi ti di ara rẹ sinu rẹ. Emi ko si mọ, mo de oko mo ba ewe mo gbe ewe ni.' Iyawo rẹ tun ni, 'Iwọ de oko o ba ewe o gbe ewe, o ko mọ elewe ati on ti o wà ninu ewe! Ẹniti o ba ti gbe ewe ni igbekugbe dandan ni ki oluwarẹ gbe ijangbọn mọ ewe.'





"Nigbati iyawo ẹkun sọ bayi inu tubọ bi i o wa bẽre o ni, 'Ewo ni ṣiṣe bayi?' Iyawo rẹ ni, 'O jẹ lọ wi fun ọba ki ẹ wa bi ẹ ti mã ṣe ti ologbo-ijakadi yi si, eyi mà su mi o.'

"Ẹkun gba imọran iyawo rẹ, nigbati o si di ọjọ keji o lọ sọ fun ọba. Nigbati ọba gbọ itan nã o ya a lẹnu gidigidi o ni, 'Ẹranko nã tilẹ fẹ ṣe nkan pẹlu rẹ ni, afi bi o ba mura dãdã bi ó ba di ọtunla ki o jẹki nri ọ.'

"Nigbati o di owuro ọjọ keji ẹkun pa agbọnrin meji o fi wọn ranṣẹ si ọba ki inu rẹ ba dun si i.

"Igbati o di ọjọ kẹta o lọ si ọdọ ọba gẹgẹ bi ero wọn, nwọn si pa ero bi awọn o ti ṣe ti awọn o fi le mu ẹranko nã. Nwọn pa ero bayi pe ki ọba se ase nlà kan ki o si pe gbogbo awọn ẹranko si ase nã ki o ranṣẹ pataki gãn si ologbo-ijakadi gẹgẹ bi àmì wipe on fẹran rẹ pupọ. Eleyi yio jẹ ọna pataki lati fi mu ẹranko nã, nitori, lọna kini, ologbo-ijakadi fẹran onjẹ ju ẹgbẹ rẹ lọ, lọna keji pẹlu, biotilẹjẹpe ki iṣe ọran jagudapāli pe ki ẹniti ọba ba pe wa, sibẹsibẹ, oju yiya ni yio jẹ bi ọba ba pe ẹnikan ti o kọ̀ lati wa. Ṣugbọn gẹgẹ bi eto wọn, gbogbo owo ti ọba ba mã na lọjọ nã, ẹkun ni yio san a.

"Ki a má fa ọrọ gun lọ bi ilẹ bi ẹni, ọba gbe agogo si ode o lu u o pe gbogbo ẹranko ki nwọn wa jẹ ase ni ãfin on, o da ọjọ mẹsan fun wọn.

"Lẹhin eleyi wayi, ọba ran ọlọpa ibilẹ meji ti nwọn ti gba okùn, obinrin meji pataki ni ãfin pẹlu iwẹfa meji ti o ba awọn obinrin nã lọ, o tun ran ìlàrí meji pẹlu ijoye meji ti nwọn ṣe pataki lãrin awọn ẹranko o ni ki nwọn lọ si ọdọ ologbo-ijakadi ki nwọn ki i fun on ki nwọn si wi fun u pe ki o maṣe ya a lẹnu rara lati ri i wipe on ran awọn ti on ran, on ṣe bẽ nitori on

fẹ fihan pe on fẹran ologbo-ijakadi pupọ ati wipe on fẹ fi i ṣe ọrẹ ki o mã wọle ki o mã jade ni ãfin ki o si di ẹni ọ̀wọ̀ ni ãrin awọn ẹranko.

"Nigbati awọn wọnyi de ọdọ ologbo-ijakadi ko fihan rara pe on mọ ero wọn. O ṣe wọn ni alejo de ibi gẹ̃, o yọ̀ mọ wọn gãn, o si ranṣẹ pada wipe ki ọba mã reti on ninu aṣọ nla, on ati idile on ni ọjọ ase nla nã.

"Werewere ologbo-ijakadi lọ wa awọn òkété mejilã o fun wọn ni owo o si fun wọn ni onjẹ o ni ki nwọn bẹrẹsi gbẹ ilẹ, ki nwọn gbẹ ẹ lati ile on de iyãra ọba ni ãfin. Werewere awọn nã mura nwọn nba iṣẹ lọ. Lẹhin eyi, o lọ si ọdọ awọn ẹiyẹ inu igbo o gba onirũru iyẹ lọwọ wọn.

"Akukọ kọ aikọ ni ọjọ ase yi, o ji iyawo rẹ̀ o mu oje igi ti o lagbara gbogbo o fi pa ara o si wi fun iyawo rẹ̀ ki o mã to awọn iyẹ wọnni mọ on lara, nwọn to iyẹ mọ ọ lara patapata o wa ku oju ati ẹsẹ. O mu ẹfun on osùn o fi ṣe ọnà si oju patapata o si tun mu ẹfun on osùn o fi pa gbogbo ẹsẹ o si wọ bata idẹ, ko si ẹni nã ti o mọ ologbo-ijakadi ri ti o le wipe on ni mọ ni ọjọ ti a nsọ yi.

"Bayi ni ẹranko nã ṣe, nigbati o si ri i pe ọpọlọpọ awọn ẹranko ti pe si ibi ase, o bọ si inu iho o mura o di ile ọba. O de iyãra ọba gãn ni gbogbo awọn ẹranko fẹ bẹrẹsi mã jẹun, nigbati o si mọ pe ko si ẹnikan ni iyãra nã mọ ti gbogbo wọn wà ni ọ̀dẹ̀, o bọ si iyãra.

"Lairotẹlẹ ologbo-ijakadi kigbe nla o ni, 'Gbogbo ara aiye o ! — ! — ! — ! — gbogbo ara aiye o ! — ! — —!— baba ọba ti ode ọrun de o ! — ! — ! — ! —.'

"Nigbati ologbo-ijakadi ke bayi lati inu iyãra gbogbo awọn ẹranko dakẹ minimini. Were o si ilẹkun nigbati nwọn si ri i ti nwọn si nfẹ salọ o ni ki nwọn má sa wipe on ni baba ẹkun ati wipe inu on dun lọrun





l'o jẹki on wa, inu on dun pupọ lati ri i bi ọmọ on ti nṣe ariya ni ode aiye ni on wipe ki on wa bẹ ẹ wò. Imu ni ẹranko nã fi nsọrọ fun wọn ohùn rẹ̀ dabi ohun ẽgun ko si si ẹnikẹni ninu awọn ẹranko nã ti o le mọ rara wipe ki iṣe baba ọba ni. Were gbogbo wọn njo yi ologbo-ijakadi ka nitori ọba pãpã fi ijo si i, ẹniti ologbo-ijakadi ba rẹrin si lọjọ nã oluwarẹ a mã fi ṣe fọrifọri ni. Erin jo titi igi fi nwo, ẹkun jo titi o tẹ ẹranko meji pa, ọbọ takiti titi ori rẹ̀ fi bó, agbọnrin jo titi iwo ori rẹ̀ fi kan danu, ayọ nã si pọ pupọ fun ọba ni ọjọ yi nitori baba rẹ̀ ti ọrun wa ki i.

"Nigbati o ṣe ologbo-ijakadi ni on fẹ jẹun ; kiakia ni ọba paṣẹ ki nwọn gbe eyi ti o dara julọ ninu onjẹ nã fun u. Igbati onjẹ de ologbo-ijakadi ni ki ẹkun wa fi onjẹ nã nu on eleyi si jẹ nkan ayọ patapata fun ẹkun nitori iyi ni fun u pe on ni anfani ati fi onjẹ nù u. Nigbati o pẹ ti o ti nfi onjẹ yi nù u, ologbo-ijakadi wi fun u ki o lọ re ẽkan rẹ̀ nitori o ngun on lẹnu, o ni, 'Lọ re ẽkan rẹ ṣọbọlọ.' Were ni ẹkun re ẽkan rẹ̀.

"Nigbati aiyederu baba ọba yi jẹun tan o sọrọ ẹkun dãdã niwaju awọn ẹgbẹ rẹ̀ o ni o fi onjẹ nã si on lẹnu dãdã, bi on ti fẹ, ati pe nitori o ṣe iṣẹ nã dara bẹ̃, on fẹ ṣe õgun pataki kan fun u loju awọn ẹranko. O ni ki ẹkun tẹ ọwọ silẹ ẹkun si ṣe bẹ̃: nigbati o ṣe bẹ̃ tan ologbo-ijakadi ṣe igbọnsẹ si i o ni, 'Nkan pataki ni iwọ nwo ni, igbọnsẹ ara ode ọrun ni, fi igbọnsẹ nã ra ori rẹ.' Pẹlu ayọ ni ẹkun fi ṣe eyi pẹlu. O fi igbọnsẹ ologbo-ijakadi ra ori, ori ẹkun ri mọ̀yanmọ̀yan o si bẹrẹsi rùn bi ọ̀bẹ̀ ijọ mẹjọ. Ẹkun di ẹniti nru igbọnsẹ ologbo-ijakadi kiri, igbọnsẹ onigbọnsẹ, ọkẹ aimoye awọn eṣinṣin fi atari ẹkun ṣe ibugbe, igbamiran on pãpã a ti gbagbe ijangbọn ti on gbe le ori, a fi ọwọ

kan ori, igbẹ a si tun ba a ni ọwọ ara rẹ si bẹrẹsi rùn lati ori de isalẹ koko.

" Eyiti o si tilẹ tun wa buru ju gbogbo rẹ patapata ni pe ologbo-ijakadi tu itọ si ẹkun lọwọ o ni ki o fi ra oju ki o si tọ ọ si ẹnu, ẹkun si tun ṣe bẹ̃, igbati o wa ṣe eyini tan ni o ni ki ẹkun tun gbe ori rẹ wa ki on fọn ikun si i, ẹkun tun ṣe bẹ̃ on nã si fọn ikun le e lori. Iwọ ọrẹ mi, o ko ri i wipe ika ni ẹranko nã dan ?—O yagbẹ le ẹni ẹlẹni lori tan, o tutọ si i ni atẹlẹwọ, o tun fọn ikun le ori olori.

" Pẹlu ayọ ni ẹkun gba gbogbo iwọsi wọnyi, nitori nkan iyi nla ni wipe on ni baba ọba nfi iyi fun tobẹ̃.

" Ki a má sa fa ọrọ gun lọ titi, bẹ̃ ni ologbo-ijakadi fi iya lọ ẹkun titi ilẹ fi ṣu ti o ki gbogbo awọn ẹranko ti o wà nibẹ ti o sure fun gbogbo wọn ati fun ọba pẹlu, lẹhin eyini ti o bọ si iyãra ti o yi wọ inu iho ni tirẹ lẹhin ti o jẹun yo bamubamu.

" Nigbati o di owurọ ọjọ keji ologbo-ijakadi wẹ, o ṣe fãri dãdã, o wa lọ duro si eti omi ti o pin ile rẹ ati ile ẹkun ni iya, o ke si ẹkun o ni, ' Ọrẹ mi, o ku ãrọ yi o, o si ku igbadun àná, ṣe àná dun dãdã ? '

" Nigbati o wi bayi ẹkun nã fesi o ni, ' Iwọ olori-buruku, tani iwọ nba sọrọ ? Ṣe ẹṣẹ rẹ l'o nle ọ kiri, ṣe on l'o le ọ ti o ko wa wo nkan àràmọ̀dà ti gbogbo wa ri lana. Lọ bẽre lọwọ gbogbo awọn ẹranko, nwọn o si wi fun ọ ohun ti o ṣẹlẹ lana. Ṣe ọwọ rẹ ni emi kò ti jamọ nkankan, emi ki iṣe ẹni kekere lọwọ awọn ẹranko. Mo fẹ sọ fun ọ, emi ni iyi lọwọ awọn ara aiye, emi tun ni iyi lọwọ ara ọrun. Ẹrankẹran ti o ba ri, bi i lẽre, yio si wi fun ọ pe baba ọba ti ode ọrun wa lana, ko ṣi ẹran nã ninu gbogbo awa ti a wa si ãfin lana ti yio wipe baba ọba yẹ on si bi emi lana. Wo ori mi, õgun ti mo fi ra a lana ko iti itan nibẹ, baba ọba ni o fi fun





mi, ọba pãpã ko tilẹ ri gbà ninu õgun nã. Ãnu rẹ ṣe mi, iwọ ologbo-ijakadi, ẹṣẹ rẹ nle ọ kiri, o nle ọ kakiri ode aiye o si nmu ọ padanu ọpọlọpọ nkan. Ṣugbọn sibẹ, o nsa kiri bẹ̃ ṣa ni, ọwọ mi nbọ wa bà ọ ni ijọ kan, emi gãn ni mo mã ri ẹhin rẹ.'

" Bayi ni ẹkun wi fun ologbo-ijakadi, iwọ ọrẹ mi ; nigbati onitọhun nã si mã da a lohun, o fun u ni esi ti o jẹ pe ibanujẹ ẹkun ko ṣẽ sọ. Ologbo-ijakadi ko awọn iyẹ lọwọ, igbati o si na iyẹ wọnni soke o ni, ' Ẹkun, ẹkun, ẹkun, ãnu rẹ mà ṣe mi o, o ko mọ pe ẹniti a ko ba le mu ọwọ Ọlọrun Ọba ni a nfi i le ! O nlepa mi nitori emi kere, iwọ kò mọ pe bi ọwọ ọmọde ko ti le to pẹpẹ bẹ̃ nã ni ti agbalagba ko le wọ akengbe ! Ko si baba ọba kan nibikan, ologbo-ijakadi ni baba ọba. Wo o, iyẹ ana ni yi, emi ni mo tò wọn mọra ; wo o ẹfun ati osùn mi ni yi, emi ni mo fi wọn pa ọwọ ati ẹsẹ mi, emi ni mo yagbẹ si ọ lori, emi ni mo tu itọ si ọ lọwọ, emi ni mo si fọn ikun si atari rẹ : wo bata idẹ, eyiti mo wọ̀ si ẹsẹ nigbati mo njo lana ni yi, emi ni mo joko ti mo wipe ki o mã fi onjẹ nù mi, emi ni mo si wipe ki ọ lọ re ẽkan rẹ ti o ri ṣọbọlọ. Nitorinã, ẹkun, iya mà jẹ ọ o, tun lọ wi fun iyawo rẹ iya ti mo fi jẹ ọ lẹhin ti mo pa ọ l'ọmọ jẹ tan. Ki ori rẹ gba ọ lọwọ wahala rẹ yi, lọwọ ijangbọn ọsan ati ijangbọn oru ati lọwọ rogbodiyan airotẹlẹ gbogbo, mo fẹ ki o mọ pe o ko le ri nkan fi mi ṣe rara, emi ni mo mã ri ẹhin rẹ.'

" Nigbati o pari ọrọ rẹ tan o fo soke o rẹrin nla o ni, Emi ologbo-ijakadi, a bi igbọnsẹ̃ bo ori ẹkun mọlẹ bàtàkùn.'

" Bayi ni ẹranko nã bẹrẹsi fi ẹkun ṣe yẹ̀yẹ́, nigbati ẹkun ronu titi o bu si ẹkún, ẹkún nã l'o sun lọ si ile.

" Nigbati o de ile ti, iyawo rẹ ri i ti o nsọkun ti o bẹrẹsi bi i ko tete sọrọ rara igbati ọ si mã sọrọ, o sọrọ

pẹlu ikanra o ni, ' Iyawo, ologbo-ijakadi fi 'gbọns
ra mi lori.' Iyawo rẹ ni ' Hĩn, kil'o ti wi ? ' O si tu
dahun bayi pe ' Ani Ologbo-ijakadi fi 'gbọnsẹ ra m
lori.' Iyawo rẹ tun bẽre o ni, ' Ologbo-ijakadi fi 'gbọns
ra ọ lori ? ' Ẹkun kò tun fesi mọ nitori inu nbi i
iyawo rẹ ba patẹwọ popo o rẹrin ke ke ke o ni, ' Ew
ni ti 'gbọnsẹ kẹ, ologbo-ijakadi fẹ pa ọ ni ? ' Iyaw
ẹkun ba fi igbe ta o ni ' Ẹ gba mi o, ologbo-ijakad
mà fi 'gbọnsẹ ra ọkọ mi lori o.'

" Bayi ni iyawo rẹ ke o si gba ọkọ rẹ ni iyanju p
ki o lọ tete sọ fun ọba ki nwọn wa bi nwọn ti mã ṣ
ọran ologbo-ijakadi si. Were ẹkun nã dide o di il
ọba. Nigbati o de ọhun o ko ohun gbogbo ti oju r
ri silẹ o ro o patapata. Ọba pãpã ko mọ igbati o
bẹrẹsi rẹrin, igbati o si wo ipakọ ẹkun o tun ri di
ninu igbọnsẹ ti o kù bẽni ẹkun ti gbiyanju ati nù u
nù o. Ọba ni ' Njẹ ara igbọnsẹ nã kọ ni yi ni ipak
rẹ yi ? ' On nã dahun o ni ' Mo tilẹ ti fi ori ra igi f
ori ra igi ori nfọ mi.'

" Nigbati ọba ronu titi o wa pinnu nkan ti o le ṣe
ti yio fi fẹ oju ologbo-ijakadi ku nitori iru iwa ti o hù
nã bi i ninu, lọna kini, oju yiya pataki l'o jẹ si ọba
pãpã, ọba pe e si ibi ase ko wa asẹhinwa asẹhinbọ
ọba pãpã tun nilati dọbalẹ fun u lọjọ ọdun ti a nsọ
yi nitori o ṣebi baba on ni. Ọran nã ko dara rara,
ẹranko nã fi oju wọn ri nkan.

" Ero ti nwọn tun wa pa ni pe, ki ọba ṣe bi ẹnipe
ko gbọ nkankan, ki o lọ ranṣẹ pe ologbo-ijakadi pe ki
o wa igbati o ba de ki o di ẹkun si inu apo kan ki o gbe
apo nã fun u wipe ki o lọ fọ ọ fun on.

" Lõtọ nwọn ranṣẹ lọ pe ẹranko nã ni ọjọ kan ọba
si gbe apo yi fun u, o ni ki o lọ fọ ọ fun on ninu odo,





ki o fọ ọ ki apo nã mọ dãdã. On nã gba a pẹlu ayọ, o wi fun ọba pe on o fọ apo nã ni kiakia, o lọ.

" Ologbo-ijakadi mọ pe ẹkun ni o wà ninu apo ki o to gba a, bi o si ti jade okùn ni o wa ti o fi di apo nã lẹnu ti o fun u tobẽ ti o fi jẹ pe ẹkun ko le jade afi bi nwọn ba tu u.

" Nigbati o ṣe bayi tan o gbe ẹkun o nlọ, nigbati o rin diẹ o ri agbẹdẹ kan o si ya si ibẹ, o rọra mu ọwọ o fi tẹ apo wo o si ri ibiti ori ẹkun wà, igbati o ṣe bẽ tan o bẹ alagbẹdẹ, ki o fun on ni ọmọ owú, onitọhun nã si fun u, nigbati ọmọ owu de ọwọ rẹ tan o fi gbogbo agbara gbe e o fọ ọ mọ ẹkun lori, agbari ẹkun si tuka, ibẹ ni ẹkun pari aiye tirẹ si.

" Lẹhin eyi ẹranko nã gbe apo lọ si odo o fọ ọ o si mu u wa si ọdọ ọba. Ọba gba a pẹlu itiju ati pẹlu ibẹru nitori ko ri ibi fi ara pamọ si mọ o ti wa daju pe ibi ologbo-ijakadi ni o nwa ọrọ nã si tun ba a lẹru nitori ko gburo ẹkun bẽni ati bẽre rẹ lọwọ ologbo-ijakadi ti di itiju ati iṣoro, ṣe ni awọn mejeji fi imu ki ara wọn, on wọ iyẹwu, onitọhun nã ba ile rẹ lọ.

" Nigbati ologbo-ijakadi de ile, o da ina o si sun ẹkun, o kun u, o ge e wẹlẹwẹlẹ, o ni ki iyawo on ko o si ikoko, onitọhun nã si ṣe bẽ, nwọn se ẹran nã o jina patapata.

" Inu ologbo-ijakadi dun pupọ bi o ti nwo ẹran ẹkun ninu ikoko o si mura o ṣire lọ si ọdọ aja ni agbẹdẹ nitori aja ni alagbẹdẹ.

" Igbati o de agbẹdẹ o ba aja nibiti o ti nfi ina o si wi fun u ki o jẹki on ba a fi i, aja dupẹ o si fun u ni ẹwiri. Igbati o mọ pe ọwọ on ba ẹwiri tan o bẹrẹsi fi ẹwiri sọrọ bayi wipe : ' Ikoko ẹkun ni ile bẹrẹkẹtẹ, bẹrẹkẹtẹ, bẹrẹkẹtẹ, ikoko ẹkun ni ile bẹrẹkẹtẹ, bẹrẹkẹtẹ, bẹrẹkẹtẹ ete'—bẽni aja mọ itumọ ẹwiri. Igbati o ṣe

aja rọra dide o ni on fẹ bọ si ẹhinkunle; kò bọ si ẹhinkunle kan ile ologbo-ijakadi l'o lọ. Nigbati o de ọhun o ba iyawo rẹ o ni, 'Bāle rẹ ni ki ngbe ikoko ẹkun ti o se wa.' Eleyi ya iyawo ologbo-ijakadi lẹnu, ṣugbọn nigbati ko jẹ pe aja mọ nkankan nipa rẹ tẹlẹ ti o si wa bẽre bẹ̃ o gbà pe ọkọ on l'o ran a.

"Were ti aja ti gba ikoko ẹran tan ile rẹ l'o ba lọ. O de ọhun o jẹ iba ti o le jẹ o ko iyoku si inu ikoko ọbẹ tirẹ o gbe ofo ikoko ranṣẹ si iyawo ologbo-ijakadi, lẹhinnã o pada lọ si agbẹdẹ.

"O ba ologbo-ijakadi nibiti o gbe nfi ẹwirì ṣire ti o nwipe 'Ikoko ẹkun ni ile bẹ̀rẹ̀kẹ̀tẹ̀, bẹ̀rẹ̀kẹ̀tẹ̀, bẹ̀rẹ̀kẹ̀tẹ̀,' o si dakẹ o ki i, o ni o ku iṣẹ o, on nã si mu ọmọ owu o nfi lu irin.

"Igbati o pẹ diẹ o gba ẹwiri lọwọ ologbo-ijakadi nibiti onitọhun ti nfi ẹwiri wi kikankikan pe 'Ikoko ẹkun ni ile bẹ̀rẹ̀kẹ̀tẹ̀, bẹ̀rẹ̀kẹ̀tẹ̀, bẹ̀rẹ̀kẹ̀tẹ̀,' on nã wa bẹrẹsi fi ẹwiri dahun o ni, 'Mo jẹ ẹ tan, mo jẹ ẹ tan porogodo, porogodo, porogodo, mo jẹ ẹ tan, mo jẹ ẹ tan porogodo, porogodo, porogodo.'

"Nigbati ẹranko nã bẹrẹsi ṣe akiyesi ọrọ yi ara fun u, o dide o ni on fẹ lọ si ile. Bi o ti de ile ni o ke si iyawo rẹ o ni 'Ikoko ẹkun mi nkọ?'

"Eleyi ya iyawo lẹnu o ni, 'Ṣebi iwọ l'o ni ki aja wa gbe ikoko ẹkun lọ! Ṣe o ko tilẹ wipe emi mã jẹ nibẹ, tabi mo mọ bi ẹ ti ṣe sọrọ pọ titi o fi kan ikoko ẹkun ni?'

"Kini ologbo-ijakadi gbọ bẹ̃ ṣe!—Oju rẹ ti pada kiyakiya nitori o jẹ ẹranko ti o fẹran onjẹ, ṣugbọn ko gbọdọ lọ sọ fun ọba, ile ẹjọ awọn ẹranko ni o lọ. Kọlọkọlọ ni alaga ninu ile ẹjọ wọn nitori o jẹ ọlọgbọn ninu awọn ẹranko igbati o ba si joko tan ni awọn oluranlọwọ rẹ to mã joko. Awọn ti o nran a lọwọ ni Ọgbẹni Ajanaku, Ọgbẹni Ìmàdò, Ọgbẹni Àgbàlàngbó, Ọgbẹni Ìnàkí, Ọgbẹni Agunfọn, Ọgbẹni Ẹfọ̀n, ati Ọgbẹni Ikõko. Ikõko ni o mã njoko tẹle Kọlọkọlọ ti o jẹ alaga nitori o jẹ ibatan rẹ. Gbogbo awọn wọnyi ni nwọn si ti mọ iru ẹranko ti ologbo-ijakadi jẹ.

"Igbati o tilẹ kọ de ile ẹjọ nwọn ko ri aye da a lohun nitori nwọn nṣe ẹjọ kan lọwọ. Ijimere ni nwọn pe ni ẹjọ nã. Ijimere jẹ ọga ile ẹkọ awọn ẹranko, ibiti o si ti nkọ akata lọna ti yio fi mọ ibiti takute ba wà ni idi ọgẹdẹ, ti akata ko tete mọ ọ, o gba a ni inu, ẹjẹ ni akata bẹrẹsi ṣu, ẹjẹ nã l'o si pa a, awọn ara ile akata ba pe Ijimere l'ẹjọ, ẹjọ nã si le gidigidi. Lãrin awọn ẹiyẹ ni awọn ẹranko ti mã ngba Lọyà wọn bi ẹjọ ba de nitori awọn ẹiyẹ le sọrọ pupọ. Lọya Ijimere ni akoko yi si ni ìbãkà, ṣugbọn ko ri aye wa ṣe ẹjọ nã nitori idiwọ ile, Adaba ni o ranṣẹ si ki o ṣe ẹjọ nã fun on bẹni jẹ̃jẹ̃ Ọgbẹni Adaba pọ jù, Adaba ba ẹjọ Ijimere jẹ, o nṣe ẹnu kábokàbo a si mã pe woro ọrọ kan ni igba ẹgbãgboje. Ọrọ nã buru fun Ijimere, nwọn fi i si ẹwọn aiyeraiye, nwọn ni ki o mã gun igi titi ọjọ aiye rẹ, on ati iran ọmọ rẹ lailai. Ati ọjọ nã ni Ijimere ti di ẹranko ti o ngun igi kiri.

"Nigbati nwọn pari ẹjọ Ijimere tan ni nwọn to gbọ ẹjọ ologbo-ijakadi, nigbati o si ro ẹjọ fun wọn ko wipe ẹran ẹkun ni aja jẹ, o sa wipe o ji on ni ẹran jẹ ni, bi o ba daruko ẹkun oju kannã ni nwọn iba pa a si, nitori ijoye pataki ni ẹkun lãrin awọn ẹranko.

"Nigbati ologbo-ijakadi ro ẹjọ tan nwọn ranṣẹ lọ mu aja wipe ki o wa ro ti ẹnu rẹ bi o ti ṣe hu iru iwa ole bẹ̃. Ṣugbọn ki ẹniti nwọn ran to de ile aja, aja ti sun ti ina o fi epo pa ara o mu ẹyin adiẹ meji o ko o si ẹrẹkẹ. Igbati nwọn jiṣẹ fun u, o ni ara on ko ti le lati oṣu mẹta ati nitorinã on ko tilẹ ti ifi oju kan ologbo-

ijakadi lati ọjọ ti ara on ko ti lè. Ọlọpa ti nwọn ran wa wipe dandan o nilati tẹle on, aja nã ba mu ọpa o nfi tilẹ̀ lọ.

" Nigbati o yọ si awọn ẹranko ẹnu yà wọn pupọ nigbati o si mã ro ẹjọ o ni, 'Lati oṣu mẹta ni mo ti nyagbẹ ti mo nbì.' Bi o ti wi bẹ̃ tan o fi ehin fọ ọkan ninu awọn ẹyin ẹrẹkẹ rẹ̀ o pọ̀ ọ silẹ, gbogbo awọn ẹranko si ṣebi ẽbi ni. Nigbati nwọn si mã dajọ nwọn da ologbo-ijakadi lẹbi iku, kumọ ni nwọn si fi lu u pa.

" Bayi ni nwọn pa ologbo-ijakadi, oṣuwọn ti on ti fi wọ̀n fun ẹkun nã ni nwọn fi wọ̀n fun u, igbati nwọn lu u pa tan nwọn pin ẹran rẹ̀ si oriṣiriṣi ọna, nwọn pin i lãrin awọn ẹranko.

" Iwọ ọrẹ mi, mo ro pe eyiti mo sọ ni ti alẹ yi to, mo fẹ lọ sun, mo si woye pe orun ko ni pẹ kun iwọ nã, o d'ãrọ o, ki Olodumare jẹki a fi ire pade lọla."

Lẹhin igbati Ireke-onibudo sọrọ bayi tan, o dide, o wọ iyãra ibiti a fun u ni ile wa wipe ki o mã gbe, o ti ilẹkun rẹ̀.

Emi nã wọle tọ iyawo mi lọ a si sun lọ ni tiwa.



## ỌJỌ KEJI ALABAPADE ÌRÈKÉ-ONÍBÙDÓ.

O pẹ diẹ ki nto ji ni owurọ ijọ keji, iyawo mi ti ji nwọn si ti fẹrẹ wa onjẹ tan. Bi mo ti dide ti mo yọju si iyãra bayi, Ireke-onibudo ni mo ri, o dahun o ni, 'Ọrẹ mi o ku ãrọ yi o,' Emi nã si fesi mo ni, ' Hõ, a o ji bi ? Ẹ ku abọ ana o.'

Lẹhinnã mo dide mo bọ si ita, mo mu orín mi mo nrùn u, ibiti mo si ti nṣe eyi ọkunrin nã dahun o ni, 'Tete parada, tete parada, ọrẹ mi, ọjọ nlọ.' Nko tilẹ kọ mọ pe emi ni o nba sọrọ afi igbati o tun kọju si mi ti o ni, 'Ọrẹ mi, iwọ ni mo nba wi.' Igbati o wi bayi tan ni emi nã fesi, mo ni, 'Tabi emi l'ẹ nba wi? Ẹ jọwọ ẹ mu sũru diẹ o, orin ni mo ṣẹṣẹ nrùn lọwọ, igbati mo ba ṣe eyini tan ng o bu omi s'ara, lẹhin nã, ẹnyin ati emi o wọle a o fi onjẹ si ẹnu, ẹhin nã wayi ni iṣẹ oni to bẹrẹ.

Bayi ni mo wi, ko si da mi lohun mọ, o bọ si iyãra rẹ̀ on ati awọn ọmọ rẹ̀ si bẹrẹsi ọrọ isọ. Nigbati mo wẹ̀ tan mo ke si i ki a wa jẹun, igbati a si jẹun tan wayi ni mo to wa bọ si ọ̀dẹ̀ mi ti mo joko ti mo pe on nã ti o joko ti mi, igbati o si joko tan ni o wi fun mi pe ki ntun awọn ohun ikọwe mi ṣe, emi nã si ko wọn jọ, mo wi fun u pe mo ṣetan on nã si bẹrẹsi ọrọ isọ o wipe:

" Ọrẹ mi, mo dupẹ lọwọ rẹ fun ãjọ̀ mi ti o ti bẹrẹsi ṣe lati ana, ọmọ enia ni ọ, ọmọluwabi ni ọ, ẹmi pataki mbẹ ni inu rẹ, ẹmi ti igbe ni ga, ti iṣe enia ni pataki, ilmu ki aiye ẹni dara ; o ṣe e pupọ, o ṣe e gãn, mo si dupẹ lọwọ iyawo rẹ pẹlu, on nã ṣe e fun wa, emi ati awọn ọmọ mi. Ko ni ṣai yà ọ lẹnu nigbati mo ji ni owurọ yi ti mo nkan ọ lọju, nko dẽde ṣe bẹ̃ rara, iṣẹ

ti mo fẹ ki o ṣe ki iṣe kekere rara, riran ni a ran mi si ọ wipe ki o sọrọ ti ng o ba ọ sọ fun awọn ọmọ enia, nko si fẹ ki o fi ọkan pe meji, mo fẹ ki o jiṣẹ nã bi ng o ti ran ọ.

" Emi ni Ireke-onibudo, emi ni mo ri ọ nigbati iwọ wà ni kekere, emi ni alakisa nã ti o duro ti ọkunrin alaṣọ funfun ẹniti orukọ rẹ njẹ Adeọrun ti o jẹ ọkan ninu awọn ẹda ọwọ Olodumare ti ngbe ode ọrun. Enia ni emi, ṣugbọn Adeọrun ti fi ọgbọn ode ọrun han mi, oju mi si ti ri ọkẹ aimoye nkan ni ode aiye, itan igbesi aiye mi gãn ni ng o si wi fun ọ loni. Ng o wi fun ọ nitori ẹhin ọla, ki awọn ọmọ enia ba le mọ pe aiye kun fun ọ̀pọlọpọ nkan, o kun fun igi ẹlẹgun ati kòtò jijin, oke giga ati igbo didi, o si kun fun ogunlọgọ ọna ti Ẹlẹda le fi jẹ ni ni iya ti o si le fi gbe ni si ibi giga. Emi, Ireke-onibudo, ti rin pupọ, mo ti rin pupọ, mo rin pupọ gãn ni, mo de ilu awọn oku nibiti Ilẹpa nṣe olori wọn, mo de ilu awọn ẹja nibiti mo wà lọwọ Àrọ̀-gìdìgbà, gbogbo nkan wọnyi ni ng o sọ fun ọ loni.

" Nigbati iwọ ri mi pẹlu Adeọrun ni ijọsi mo ti kuro ni ọmọde, nigbanã, mo wà ninu wahala ti o tobi tobẽ ti a ko le gbadura iru bẽ fun ọmọ ẹni. Nko ni nkankan lọwọ, ẽpinni pere l'o wà ninu apo mi nigbati o ri mi.

" Emi ni Ireke-onibudo, baba mi si ni Ireke-aiye, awọn enia npe e bẽ nigbati o wà laiye nitori aiye rẹ̀ dun bi ireke nigbakan. Iyawo ti baba mi ni jẹ meji-lelogun, ọmọ rẹ̀ si jẹ mejilelọgbọn, emi ni akọbi baba mi, emi ni arẹmọ, iya mi si ni agba gbogbo awọn aya baba mi. Igbẹhin baba mi kò dara, aiye rẹ̀ kò ba si ti ri bẽ bi o ba jẹ pe o fi eti si imọran iya mi, ṣugbọn ogunlọgọ obinrin, ogunlọgọ wahala ni nmu ba ni. Gbogbo obinrin ti baba mi ko jọ, kò njẹ ki iya mi mọ nipa wọn titi nwọn fi nwọle afi awọn meji ti o fẹ tẹle





iya mi gãn. Igbati awọn obinrin pupọ wọnni ti wọle ni o ti di pe iya mi ko ri oju baba mi ni ilẹ mọ, gbogbo imọran ti o yẹ ki o bẽre lọwọ iya mi, ko jẹ bẽre, a bẽre lọwọ awọn ọmọ ẹhin rẹ̀. Nigbati o ṣe, o fẹ ọmọ olowo kan, iyawo nã l'o si sọ fun baba mi pe baba on nfẹ ko ẹgbẹ oniṣowo jọ ati wipe o yẹ ki baba mi wà ninu ẹgbẹ nã. Baba mi yọ̀, o nfẹ di olowo nla, o ko gbogbo owo ọwọ rẹ̀ jọ o fi fun baba obinrin yi, lẹhin ti o ko ti ọwọ ara rẹ̀ silẹ tan o tun lọ ya nibomiran. Nigbati nwọn ra nkan jọ ti nwọn ko o lọ si idalẹ, ọja bajẹ, o si bajẹ tobẽ ti baba mi fi bọ si inu gbese ti ọwọ rẹ̀ ko to ẹnu mọ.

" Eyiti o buru julọ patapata ni eyi : baba mi tun ko ohun gbogbo ti iya mi ni o ta wọn lati fi san ninu gbese yi ṣugbọn kò ká a. Iyawo ti nwọn jọ pa ero nigbati ọran iṣowo yi mã kanlẹ tun kọ ọ silẹ bẽ ni gbogbo awọn obinrin nã si bẹrẹsi kọ̀ ọ titi o fi ku iya mi nikan.

" Nigbẹhin, aisan gbe baba mi lulẹ, inu aisan nã l'ó si ku si, o wa ku emi ati iya mi a kò si ri nkankan jẹun. Awọn aburo mi ti nwọn jẹ ọmọ orogun ti tuka ni ile baba mi.

" Igbati o ṣe, aisan kọlu iya mi. Mo ṣe itọju rẹ̀ de ibiti ipa mi to, nigbati o ṣe, aisan nã tubọ nburu si i, ni owurọ ọjọ kan bayi, iya mi pe mi o ba mi sọrọ ikẹhin rẹ̀ o ni :

" ' Iwọ ọmọ mi, Ireke-onibudo, bi mo ti nwo ọrọ mi yi, nko ro pe mo le yọ ninu aisan yi, bẽni nko ni nkankan silẹ fun ọ. Mo fi ọ le Olodumare lọwọ, bi mo ba ti ku tan, ṣe ni ki o jade ni ilu ki o mã lọ si ibikibi ti o ba ri. Baba rẹ ti ta gbogbo nkan ti mo ni ki ó to ku o si fi mi silẹ ni ihõho ni ode aiye, bayi ni aiye mi bajẹ loju mi, nko ṣe ẹnikẹni ni ibi ri, nko si hu iwa ika si

ọmọnikeji, jọwọ Ọlọrun Ọba, maṣai tun ẹhin mi ṣe. Ba mi tọju Ireke-onibudo ninu aiye, maṣe jẹki ó ku si wahala bi emi, Bi ọmọ yi ba pade iyọnu lode aiye, Olodumare yọ ọ, bi o ba pade-wahala, Olodumare yọ ọ, bi ipọnju owo ba si de ba a, Olodumare maṣai yọ ọ ninu rẹ̀ dandan.'

" Bayi ni iya mi sọ, nigbati o si dakẹ, o ni ki nwa gbe on lọwọ mo si gbe e, afi gbigbe ti mo gbe e tan ti o mi kanlẹ lẹ̃kanṣoṣo, o dakẹ le mi lọwọ.

" Aṣọ kanṣoṣo ti iya mi fi bora nã ni mo fi dì i nko si to ẹniti npe awọn ẹgbẹ ki nwọn wa ba mi gbẹ ilẹ oku nitori nko le ri nkan ti mo mã fun wọn jẹ, emi nikan ni mo mu ọkọ ti mo gbẹ ilẹ ti mo sin iya mi pẹlu ọpọlọpọ ibanujẹ ti iku rẹ̀ jẹ fun mi.

" Eyiti o jẹ ki nkan nã buru pupọ ni pe ko si ẹniti o ni owo rara ni iran iya mi, ko tilẹ si pupọ ninu awọn iyekan rẹ̀ ti o wà lãye, ẹgbọn rẹ̀ àgbà ti o wa lãye ti di arugbo tobẽ, oju rẹ̀ ti fọ, ko ni ehin kanṣoṣo lẹnu, bẽni lakuregbe ti sọ ọ di arọ, ọjọ iku ti on pãpã kò jina mọ.

" Eleyi yio fihan ọ pe ipo ti iya mi fi mi si nigbati o ki aiye pe o digbõṣe ko dara. Ṣokoto kan ti mo jogun ni ile baba mi l'o wà ni idi mi nigbanã, mo ni ẹwu akisa kan, eyini nã l'o ri lọrun mi niwaju Adeọrun, mo si ni ẽpinni kan si inu apo mi. Bayi ni mo si ṣe ti mo jade lãrin ilu ti mo ki ori bọ inu igbo. Fun odidi ọjọ meje ãrin aginju igbẹ ni mo wà, eso igi ni mo nka jẹ, aiye pãpã su mi, bi ẹnipe ki ẹranko pa mi jẹ l'o ri ni ọkan mi. Igbati o pẹ diẹ ti mo ti nrin ni awọn rugudu ti o mu ọ ni ijọsi ri mi ti nwọn mu mi lọ si ọdọ Adeọrun, ọdọ rẹ̀ ni mo si ti pinnu pe ng o mã rin titi ng o fi de ọdọ ẹnikan ti ng o duro tì.

" Ṣugbọn nisisiyi aiye ti yipada, Olodumare ti sọ mi





di enia, Adeọrun l'o si wi fun mi ki nlọ sọ itan igbesi aiye mi fun ọ.

" Nigbati mo de ọdọ ọkunrin nã ni ijọsi ki iwọ to de wa ba wa ọrọ ti o sọ ni-yi: 'Ireke-onibudo, o wà loni laini ẹnikan, ṣugbọn sibẹ o ni ẹnikan, o ni Olodumare, ko ni ṣai duro tì ọ, iṣoro wà niwaju rẹ, nkan wahala ati nkan lile bi akọ okuta gbogbo l'o si nduro dè ọ, ṣugbọn njẹ iwọ mọ pe ẹniti kò ba da oju kọ wahala ki o bori wahala ko ju adiẹ lọ lode aiye? Ko tilẹ to adiẹ. Nitorinã mu ṣokoto rẹ ki o fun u le, mã lọ, aiye rẹ yio dara bi wura ati fadaka, lẹhin igbati o ba ti gun oke iṣoro rẹ tan, ọjọ nbọ ti awọn ọmọ enia yio mã fà kàkà ati de ibiti iwọ de ati lati ni anfanĩ ti ó wà ni ikawọ rẹ, ṣugbọn, Ireke-onibudo, nigbati aiye ba yẹ ọ tan, maṣe gbagbe Ẹlẹda rẹ.'

" Nigbati o wi bayi tan ẹru ba mi mo si dahun mo ni, 'Ẹ jọwọ ọrẹ, ẹ maṣai sọ fun mi ẹniti ẹ jẹ, ibiti ẹ ti wa, ati ibiti ẹ nlọ.' On nã si dahun o ni,

" 'Ireke-onibudo, mo ti mọ—ọ ki iwọ to mọ mi, ọjọ ti pẹ ti mo ti nṣe akiyesi rẹ, iku iya rẹ kò ṣe ẹhin mi, aisan baba rẹ ko ṣe ipamọ loju mi, emi ni ọkan ninu awọn ẹmi ode ọrun ti awọn ọmọ araiye ko le ri, ti nṣe iranṣẹ Olodumare, Adeọrun ni orukọ mi si njẹ. Ẹmẹrinlelogun ni mo nyi aiye po lojojumọ, lati mã kọ iwa olukuluku silẹ ninu iwe iranti: awọn ẹlomiran a gba iwa rere meje nwọn a gba buruku mẹjọ, awọn ẹlomiran a gba buruku mẹwa nwọn a gba rere marun, awọn ẹlomiran a gba buruku mẹrinlelogun, nwọn ko si ni gba rere kan—gbogbo iwọnyi ni yio yọ ninu iwe mi ni idajọ wọn. Ṣugbọn, Ireke-onibudo, ayọ mi ni eyi pe rere rẹ tayọ ibi ni ori ilẹ aiye, bẽ nã si ni ti iya rẹ.'

" Igbati ó sọrọ bayi tan mo tun fun u l'esi mo ni, 'Adeọrun, iwọ ẹmi pataki ode ọrun, njẹ bi ó ba ṣe õtọ ni

ọrọ rẹ wipe rere iya mi pọ ju ibi rẹ̀ lọ, ẽha ti ri ti aiye rẹ̀ fi buru tobẹ̃ ti o ku laini nkankan ?'

“ Ọrọ yi pa a lẹrin o dahun o ni, ' Ikawọ Olodumare ni iku wà, ko si lọwọ rẹ ko si si lọwọ mi, bi ó ba ti wu Olodumare ni O nṣe nkan Rẹ̀, ohun ti Olodumare ri ẹnikẹni kò lé ri i, ẹniti o ba ti mu lọ kuro lori ilẹ aiye O ri i pe o tọ ki eleyini lọ ni, eleyi si jẹ ọkan ninu awọn nkan wọnni ti ko le ye awọn ọmọ enia ni ori ilẹ aiye.'

“ Iwọ ọrẹ mi, ibiti a sọrọ de lọjọ nã ni eyi ti awọn rugudu wọnni fi mu ọ wa ba ni, o si le ṣe akiyesi wipe nko sọ nkankan mọ nigbati o ti de ati wipe emi ati iwọ ni a jọ jade ninu igbo nã ti a jọ rin titi iwọ fi ya si ọna oko yin ti emi kọja si iwaju ni temi.

“ Ati igbati a ti jọ pinya yi, onirũru nkan abami ni o ti ṣẹlẹ si mi.

“ Nigbati mo kuro lọdọ rẹ tan mo de oko ọkunrin kan bayi mo si yà si i, ọkunrin nã kọ abà si eti ọna. Nigbati mo de ibẹ mo ba a nibiti o gbe nwa onjẹ, o nlọ ata lọwọ ni, nigbati mo si ki i tan mo bẽre ki o jẹki nba on lọ ata on, o si gba, nigbati mo lọ ọ tan mo bẽre bi o ba ni iṣẹ miran lati ṣe, o wi fun mi pe onjẹ lasan ni on fẹ wa ati wipe ki nmá ṣe iyọnu, bi mo ba fẹ mo le mã lọ.

“ Nigbati o wi bayi emi nã wa wi fun u pe mo ni ọrọ pataki kan lati ba a sọ—o dawọ duro, mo si nba ọrọ mi lọ mo wi fun u pe mo nfẹ ṣe lébìrà ni ati wipe bi iṣẹ ba wà ki ó jẹki nba on ṣe e ni oko on. Pẹlu ayọ ni ọkunrin nã si fi da mi lohun, o ni iṣẹ wà ati wipe o pẹ ti on ti nwa lébìrà ti on ko ri, wipe Ọlọrun ni o ran mi si on.

“ Bayi ni mo bẹrẹ iṣẹ ni oko ọkunrin nã. Nigbati o di ọjọ keji mo ṣe akiyesi pe o ni agbebọ adiẹ kan ti o ni ọmọ lẹhin mo si bẹ ẹ bọya o le jẹki nmã ba on





tọju awọn adiẹ nã ki a jọ mã pin ọmọ ẹhin rẹ̀, ṣugbọn o kọ̀, o wi fun mi pe afi bi mo ba mã ra ọkan ninu awọn ọmọ ẹhin adiẹ nã, bẽni nwọn kere pupọ, nwọn ko ju ọmọ ọjọ mẹta lọ. Mọ bẽre iye ti yio ta ọkan ninu awọn ọmọ adiẹ nã, o wi fun mi pe ẽpinni ni, mo si ra a bẽni mo lo epinni ti mbẹ ninu apo mi.

“ Bayi ni mo sa ṣe ti mo joko ti ọkunrin nã, adiẹ ti mo rà kò ku, o bẹrẹsi dagba, mo si nfi owo lebira mi pamọ nitori mo njẹun lọdọ rẹ̀.

“ Nigbati o di ọdun kan gẽre adiẹ mi kekere ti mo ra ti dagba o si ye ẹyin mẹjọ, mẹjẹ̃jọ l'o pa, meje si jẹ abo ọkan jẹ akukọ. O ya mi lẹnu lati ri i pe ọkanṣoṣo ko tilẹ ku ninu awọn adiẹ nã, nigbati o si tun mã di ọdun keji awọn abo wọnni tun ti ye, ọkọ̃kan tun ye mẹjọ awọn ọmọ wọn tun dagba ti eyikeyi ko ku ninu wọn bẹ̃ bẹ̃ mo di aladiẹ mo si ni to ọ̃dunrun adiẹ ki nto bẹrẹsi tà wọn. Lọjọ ti mo kọ ta adiẹ mi mo pa pọnun mẹwa l'oko wa.

“ Ọga mi ti mo wà lọdọ rẹ̀ fẹran mi bi ẹmi emi nã ko si fi nkankan pamọ fun u, o mọ iye owo ti o wà lọwọ mi, on nã l'o si fun mi ni imọran wipe eyiti mo gba lébìrà nì to o yẹ ki nda oko temi. O fun mi ni ilẹ emi nã si dupẹ lọwọ rẹ̀ pupọ. Bi ọkunrin nã ti ṣe itọju mi jọ mi loju tobẹ̃ ti nko ṣi ni ero miran lọkan mi ju bi ng o ti ṣe san õre nã fun u. Bi alejo rẹ̀ ba de ṣe ni a jọ ntọju rẹ̀, bi aisan ba si nṣe e emi ni mo lọ nwa egbo igi rẹ̀, nkò kuro lọdọ rẹ̀ lẹ̃kan.

“ Iyawo kan ni ọkunrin nã ni nigbati mo de ọdọ rẹ̀ oju mi bayi ni o si ṣe ni ekeji, eyi ekeji yi nã l'o pin wa ni iya, bayi ni :

“ Obinrin nã jẹ ẹniti ko ni ifẹ pipe si ọkọ rẹ̀, bi ó ba ti ri ẹni ẹlẹni a dabi ẹniti o gun ori oye, igbati o wà ni wunndia ọpọlọpọ ìgbà ni ọga mi mã nran mi lọ si

ọdọ rẹ̀, igbati mo ba si ni nkan emi a fun u, ṣugbọn dipo ki o fẹran ọga mi dãdã o nkọju ifẹ rẹ̀ si mi, o si nṣe ohunkohun lati fi wa oju mi mọra, ọrọ ọga mi ti o mã nsọ fun mi buru a si mã wi fun mi pe iwa mi dara ju ti ọga mi lọ, mo ni ẹwa pãpã ju ọga mi lọ, ifẹ temi wà lọkan on, on nla ala ri mi, ọkan on ko kuro lọdọ mi; bi o ba ri i pe mo ra aṣọ kan on nã a ra iru rẹ̀, bi o ba gbọ pe mo nlọ si ibikan on nã a ba ibẹ lọ, bi mo ba lọ si ile, ojojumọ ni o nwa ki mi ti o si ngbe onjẹ ranṣẹ si mi, bi mo ba ti ri i a bu si ẹrin, bi mo joko si ibikan a tẹ oju mọ mi, bi mo roju mọ ọ a fi ẹrin da mi lohun, o jẹ ọkan ninu awọn oloṣi wọnni inu eyiti eṣu jọba si, ti eṣu ti joko lori itẹ ti eṣu de ade ti nwọn nhuwa ìkọ̀kọ̀ si bale wọn.

"Nigbati o pẹ titi ti nko fẹran obinrin nã ni ifẹ aṣĩri ti o fẹ mi yi, ó bẹrẹsi korira mi, mo dabi igbọnsẹ loju rẹ̀, o korira mi lati atẹlẹsẹ de ori koko.

"Nigbati o de ile ọga mi o bẹrẹsi bà mi jẹ, ọga mi nã ko si huwa ọlọgbọn, o jẹ ọkan ninu awọn ọkunrin wọnni ti nwọn ko mọ iwa alumọkọrọyi onibajẹ obinrin, nigbati o di owurọ ọjọ kan bayi, ọga mi pe mi o ni on nfẹ ki nkuro ninu ahere on, mo bẽre idi rẹ̀ ko si sọ fun mi, bayi ni mo ṣe ti mo fi kuro nibẹ ṣugbọn oṣu kẹta ti mo kuro nibẹ ni obinrin nã kọ̀ ọ silẹ, nitori Olodumare ti ri ọkan mi pe nko ṣe ibi si ọkunrin nã.

"Mo ti ni owo diẹ lọwọ ki nto kuro ni oko ọkunrin nã emi ati ọrẹ mi kan si pinnu ati lọ ṣe òwò diẹ ni idalẹ. A ra ọnirũru nkan a dì i, a pinnu ati gbe e lọ si ilu kan ti nwọn npe ni Ero-ẹhin, awa nã ngbọ orukọ ilu nã ni a kò de ibẹ ri. Ọna inu igbo kan bayi si ni enia nba de ilu nã, ọna awọn ọdẹ ni.

"Emi ati ekeji mi ji ni afẹmọju a gbe ẹru wa, a fi ori le ọna inu igbo yi. Nigbati o to dẽde agogo mejilã





ọsan gãn a de ibi omi kan bayi, a sọ kalẹ a nmu omi. Eleyi nã ni a nṣe lọwọ afi igbati a dẽde gbọ igbe nla kan lati apa oke odo ti o nke bayi wipe 'Oluigbo O! — ! — ! — oluigbo O! — ! — ! — enia! — ! — ! — enia! — ! — ! —. Bayi ni ohun nã nke a si ti mọ pe ti iwin ni. Were a tuka mo sa gun igi lọ ni temi, ọtọ ni ibiti ẹnikeji mi ba lọ.

"Igbe yi si tubọ nbọ ni apa ọdọ mi, igbati o ṣe mo bẹrẹsi ri awọn ẹranko gbogbo ti nwọn nsa kọja lọ. Laipẹ lẹhin eyi mo ri iwin nã, o fi mariwo bo idi, mariwo nã si pọ tobẽ ti o bo o ni ẹsẹ bamubamu, o ni oju kan si iwaju ati ọkan si ipakọ, ẽkan rẹ̀ dabi ẽkan kiniun o si fi ẹfun ati osùn sa oju, oju rẹ̀ dabi ẹgbẹ ogiri ile oriṣa, o ni ẹru gidigidi.

"Nigbati o de ọdọ mi ko wo oke rara ṣugbọn o ti ri mi, o dahun o ni, 'Mo ti ri ọ, iwọ ọmọ enia, mo ti ri ọ, iwọ ẹda buruku ode aiye, mã bọ̀, sọ kalẹ ki o pade iku, joko s'ọhun ki iku wa ba ọ, oni yi ni ori rẹ yio de inu iṣãsun mi.' Bi o ti wi bayi tan o fi ẹhin ti igi ti mo wa ni ori rẹ̀ were ṣe ni ẹka ti mo joko le lori si gbe mi lọ ba a. O mu mi o fi okun nla kan bayi bọ mi lọrun o nfa mi lọ emi nã si ntẹle e. Nigbati o pẹ diẹ o mu mi de ibi okuta kan bayi, nigbati o de ẹnu ọna okuta nã o kàn a bi ẹnipe ẹnikan wà ninu ile ati wipe eleyini yio ṣi ilẹkun fun u, ṣugbọn were ni ilẹkun nã ṣi. Igbati mo wọ inu okuta nã ni mo si to mọ pe o tobi ati wipe ọpọlọpọ iyãra mbẹ ninu rẹ̀. O mu mi wọ ọkan ninu awọn iyãra ibẹ, igbati mo de ọhun o pa ilẹkun ibẹ de mọ mi. Ibiti mo wà nã ni ferese, gbangba ni mo si le ri inu rẹ̀, nigbati mo wo oke mo ri ọpọlọpọ irin ti nwọn kàn mọ ẹgbẹ ogiri mo si ri ọkẹ aimoye agbari ọmọ enia ti nwọn fi kọ ọ.

"Nigbati o ti pa ilẹkun iyãra ti mo wà de tan ni o

tun ti jade ti o pa ilẹkun gbogbo iyoku de ti o ke lọ. Nigbati o ke lọ yi mo wo inu iyãra ti mo wà dãdã mo si ri ogunlọgọ owo gõlu nibẹ ṣugbọn nkò to ẹniti iyọ̀ pe mo ri wọn nitori iku ni mo nṣe ireti.

"Ki o to de mo ke pe Ọlọrun mo ni, 'Iwọ Ẹlẹda mi, Iwọ Ẹlẹda mi, Iwọ ni Ẹlẹda mi, bawo ni aiye mi ti ri yi ? Igbesi aiye mi lati ẹhin wa kun fun ibanujẹ, Ẹlẹda mi, maṣe jẹki o pari si ibanujẹ bayi, igbesi aiye mi ko ṣe mi ni anfani sẹhin, Ẹlẹda mi, maṣe jẹki nku bayi laigbadun rẹ̀ ; aiye mi koro, Ẹlẹda mi, sọ ọ di didun ; aiye mi dàrú Ẹlẹda mi, jẹki o tòrò bi omi inu apata ; ara kan mi, Ẹlẹda mi, tù mi lara ; ọkan mi kò balẹ, Ẹlẹda, jọwọ jẹki o balẹ ; nko ni ibatan ati iyekan Ẹlẹda mi, maṣai duro bi ibatan ati iyekan fun mi. Jẹki nyọ lọwọ iwin buruku yi ki nsi fi ọran yi ṣe itan pa, gba mi o, Ẹlẹda maṣai gba mi, lọwọ ibanujẹ airotẹlẹ, gbà mi o, Ẹlẹda, maṣai gba mi ; lọwọ apanijẹ ẹbọra, gbà mi o, Ẹlẹda maṣai gbà mi.'

"Bayi ni mo ke pe Ẹlẹda mi ti mo fi ara mi silẹ fun Ọlọrun Ọba.

"Nigbati o ṣe ti mo wo iyãra ti mo wa dãdã mo ri irin olori ṣonṣo kan mo si yẹ ẹ wò bọya mo le lo o ki nfi gun ẹbọra nã loju. Ṣugbọn nigbati o tun npada bọ ti o nkigbe nla bi ti iṣãju nko to ẹniti nyọ oju si i.

"Nigbati o wọle mo ri i ti o gbe oku ekeji mi ti o salọ bọ̀ oju mi l'o si ṣe jẹ ẹ tan. Lẹhin ti o jẹ ẹ tan o fi ẹhin le ilẹ o sun lọ.

"Mo ngbọ bi o ti nhanrun nibiti o sun si mo si ri i pe gbogbo ilẹkun ni o ṣi silẹ, mo ba rọra ṣi ilẹkun iyãra ti o fi mi si, mo bọ okun kuro l'ọrun mo mu irin ṣonṣo iyãra rẹ̀ mo fi gbogbo agbara mi ki i bọ ọ loju, o dide o si nfi oju kan ti o wà ni ipakọ wa mi kiri,





ugbọn ko ri mi, mo rọra dọbalẹ mo fà jade ninu apata ã, o si bẹrẹsi kigbe kiri.

"Ilẹ ti nṣu ki nto ri aye jade, ṣugbọn oṣupa dabi san. Ẹru mi sọnu ṣugbọn nko bikita fun eyini nitori no ko diẹ ninu owo gõlu iwin nã jade.

"Emi pãpã ko mọ ọna ilu Ero-ẹhin dãdã nitori ọna wọn ọdẹ ni ibẹ nitorinã nko le de ibẹ ni ọjọ keji, o i tilẹ pẹ ki nto de ibẹ lẹhin eyi.

"Ṣugbọn ni ọjọ kẹta mo de ilu abami kan. Nigbati o wọ ilu nã nko ri ẹyọ ẹnikan ṣoṣo bẽni mo gbọ nwọn sọrọ si ara wọn, mo ngburo ẹsẹ ti o nkọja, mo ngbọ be ọja ti nwọn nta ṣugbọn nko ri ẹnikẹni. Ibiti mo i nrin ka ilu nã mo ri ile nla kan ti o dabi ãfin mo si wọ ibẹ. Nigbati mo de inu ile nã mo ba ọkunrin kan i o joko lori ibi giga kan ti nwọn tẹ itẹ si mo si ki i, ugbọn bi o ti nfẹ da mi lohun omi l'o nbọ loju rẹ̀ o sọkun.

"Nigbati o si nu oju nù o dahun o ni, 'Ọmọ enia, lu oku ni iwọ wa yi, Irẹwẹsi ni orukọ ilu yi, emi si i ọba ibẹ orukọ ẹniti njẹ Ìlèpa. Ọkan ninu awọn ẹda de ọrun ni mi ṣugbọn nigbati awọn ọmọ enia ti hu wa àbòsí si Olodumare ni iṣãju ti o di pe aiye di fọwọbàfisilẹ fun wọn ni Olodumare ti fi mi si ilu rẹwẹsi yi lati mã ṣe itọju awọn oku ti o ba ṣẹ̀ṣẹ̀ fi aiye silẹ ti o nbọ ni ọrun. Nwọn ko gbọdọ gbe ju ọjọ mẹta ni ilẹ yi ki o to di pe nwọn lọ. Ṣugbọn ẹda oniro-binujẹ ni mo jẹ, inu mi ki idun nitori gbogbo igbe ti awọn araiye ba nke nigbati ọ̀fọ̀ ba ṣẹ̀ eti mi l'o nlọ, ko si si ọjọ ti nwọn ko ni wa ba mi ni ilu yi, mo wà ninu aisimi mo ngba ọkẹ aimoye alejo ni wakati kan lojojumọ. Igbesi aiye ọmọ enia kun fun ibanujẹ, o kun fun tẹmbẹlẹkun, bilisi ati wahala, ọkẹ aimoye ọna ni Olodumare le gba fi mu ọmọ enia ni ode aiye—iku,

ọmọ, owo, aibalẹ ọkan—gbogbo iwọnyi ni Ẹlẹda le l
lati fi ba enia wi, ko si igbati mo ba ronu nipa aiy
awọn ọmọ enia ti inu mi ki ibajẹ.

" 'Ṣugbọn nigbati mo ba tun ro o lọna kan inu mi
dun nitori ọpọlọpọ anfani miran mbẹ ni ode aiye, õru
ati oṣupa, irawọ ati awọn ẹda alãye gbogbo, ẹja in
okun ati ẹiyẹ oju ọrun, eweko ori ilẹ ati awọn kokor
kekeke, omi ṣiṣàn ati awọn okuta gbogbo, kòtò at
pẹtẹlẹ, gbogbo iwọnyi jẹ nkan rere ode aiye, ninu gbogb
awọn ẹda ti Ẹlẹda si da si inu aiye ko si eyiti ipo n
to ti enia, Olodumare fẹran ọmọ enia, ayanfẹ ni eni
jẹ fun u, ati nkan ti mbẹ ni ofũrufu, ati ti inu om
ati ti isalẹ ilẹ ilo enia ni nwọn wà fun, enia si tun
ọgbọn ti mbẹ ninu agbari ta gbogbo ẹda iyoku yọ.

" 'Ibiti iwọ si wà loni yi ni anfani rẹ o si tun n
ibanujẹ rẹ pẹlu. Ibugbe oku ni, ibẹ ni awọn oku t
mã nmura ati lọ si ode ọrun; ibi isimi ni ; ko si ariw
ko si ibẹru ṣugbọn ki iṣe ibugbe awọn alãye, nitorin
o ko gbọdọ sun ni ilẹ yi mọju oni o ko si gbọdọ jẹu
ni ile ẹnikẹni, nitori ẹmi alãye mbẹ lara rẹ.

"Bayi ni ọba ilu yi sọ Ìlẹ̀pa ọba ilu oku, nigbati
si dakẹ mo bẽre lọwọ rẹ bọya o le mu mi yi ilu nã k
tabi ki o fi awọn nkan abami diẹ han mi si i.

"Bi mo ti wi bayi tan o fọn fere kan mo si ri ogunlọg
ẹsẹ ti o nrin bọ lọdọ rẹ, ẹsẹ enia ni awọn ẹsẹ nã ṣugbọ
nko ri oke ara wọn, idi wọn de isalẹ ni mo ri m
lẹhinnã mo ri i o nranṣẹ kan mo si ri ọwọ ti o nn
nkan si i ṣugbọn nko ri iyoku ara. Lẹhinnã o mu n
wọ iyãra kan lọ, nigbati mo de ọhun o fi digi nla ka
han mi, o ni ki nmã wo o mo si bẹrẹsi wo o, mo
ogunlọgọ enia ti nwọn tò lẹsẹsẹ ti nwọn nkọja o
odo kan, bi nwọn ba ti mã goke nwọn a bu diẹ m
ninu odo nã bi nwọn ba si ti ṣe bẽ nko ni ri gbogb





ara wọn mọ. Nigbati mo wo diẹ o da mi lohun o ni, 'Oku ni iwọ nwo wọnni, nwọn ki iṣe ẹni aiye mọ, nwọn ti bu omi ọrun mu.'

" Lẹhin eyi o wa mu mi lọ si ibi okuta kan, nigbati o de ibẹ o patẹwọ mo si bẹrẹsi gbọ girigiri ẹsẹ ni eti okuta. Lẹhinnã o kọju si mi o ni, 'Eleyi ni okuta Iṣiro, ibẹ ni awọn ara aiye ti mã nṣiro ohun ti o pa wọn.'

" Nigbati o ṣe mo ri i o koju si ibi okuta yi bi ẹnipe o nsọrọ si ẹnikan o ni, 'Kil'o pa ọ ?' Lẹsẹkannã ni mo si ngbọ ti oluwarẹ bẹrẹsi sọrọ o ni, 'Ọmọde ni mi ni mo kuro l'aiye, iya mi ni o gbe epo gbigbona lọwọ ti o nsare ti inu ile bọ ti o pade mi lairotẹlẹ ti epo nã si da le mi lori.' Lẹhin eyi o tun bẽre lọwọ ẹni keji, 'Kil'o pa ọ ?' On nã si nsọrọ o ni 'Ọmọde ni mi ti mo kuro laiye, iya mi l'o fi mi silẹ ti mo nsare kiri oju ọna mọto, on ni mọto ba tẹ mi pa.' O tun bẽre lọwọ ẹketa on nã tun dahun o ni, 'Ọmọde ni mi ti mo kuro ninu aiye ṣe ni iya mi gbe mi gun oke pẹtẹsi lọ ti o wa si isalẹ ti mo yọju loke ti mo ṣubu.' O tun bẽre lọwọ ẹkẹrin onitọhun nã si tun dahun o ni, 'Ọmọde ni mi ti mo kuro ninu aiye, igbati otutu mu ni iya mi ko fi aṣọ wọ mi ibẹ ni mo ti mu amodi ti o pa mi.' O tun bẽre lọwọ ẹni karun on nã si fesi o ni, 'Ọmọde ni mo jẹ ti mo fi kuro ninu aiye, eti odo kikun ni iya mi gbe mi lọ ti o kuro nibẹ ti mo fà lọ si ibi omi nã ti mo ku si i.' O tun bẽre lọwọ ẹni kẹfa on nã si fesi o ni, 'Ọmọde ni mo jẹ ti mo fi kuro ninu aiye, baba mi fẹran owo ju ọmọ lọ nigbati inu nrun mi ti nwọn ni ki o ra õgun si i ko ra a titi inu nã fi di lile ti o pa mi.' O tun bẽre lọwọ ekeje on nã si tun dahun bayi, o ni, 'Ọmọde ni mo jẹ ti mo kuro ninu aiye, jẹdijẹdi l'o pa mi baba ati iya mi ni ko tọju rẹ lakoko;'

ẹni kẹjọ tun dahun o ni, 'Ọmọde ni mi ti mo kuro ninu aiye emi l'o fi ọwọ ara mi ṣe ara mi, mo gun igi mo ja tilẹ egungun ẹhin mi da.' Ẹni kẹsan si tun fesi o ni, 'Ọmọde ni mi ti mo kuro ninu aiye, mo jẹ ọmọ lile awọn ẹgbẹ mi sọ mi ni okuta ni agbari, ori mi si fọ.' Ẹni kẹwa tun dahun o ni 'Ọmọde ni mo jẹ ti mo kuro ninu aiye ṣe ni mo yọju si inu kanga ti mo ja si i.'

"Bayi ni gbogbo wọn bẹrẹsi sọ ti nwọn nsọ iku ti o pa awọn, ọmọde si ni gbogbo awọn ti o sọrọ. Lẹhin ti nwọn sọrọ tan Ilẹpa, ọba ilu awọn oku wọnyi sọrọ fun mi o ni, 'Kiyesi awọn ọrọ ti iwọ gbọ wọnni, o ko ri i wipe nkan kekere loju awọn enia l'o nmu iku ogun-lọgọ awọn ọmọde wa? Awọn ọkunrin miran wà ni ode aiye ti nwọn fẹran owo ju ile, ti nwọn fẹ ẹ ju ọna, ti nwọn fẹ ẹ ju Ẹlẹda wọn lọ, awọn wọnni ni kò nle mu owo onjẹ lasan fun ọmọ wọn, nwọn ko si jẹ bikita fun aisan ọmọ wọn pẹlu, bẽní awọn alafara obinrin ko ni ṣai mã fi ika abamọ bọ ẹnu nipa ọmọ wọn.'

"Nigbati o pari ọrọ rẹ mo fun u l'esi mo wipe: 'Kabiyesi, Ọgbẹni Ilẹpa, ọba ilu oku, mo yọ pupọ lati ri ọ, nko gburo rẹ ri, ẹnikẹni ko si sọ itan ilu rẹ fun mi, ṣugbọn mo dupẹ lọwọ rẹ pupọ fun ọpọlọpọ nkan ti o fihan mi loni, ati ọgbọn ti o kọ mi, lõtọ o yẹ ki ọmọ enia mã ṣe akiyesi ara rẹ ṣugbọn awọn miran wà ni ode aiye ti nwọn ni oju ti nwọn ko jẹ fi riran ti nwọn ko jẹ ṣe akiyesi nkan kekere, awọn wọnni ni nmu ki ijamba ṣe ọmọ. Nko ni gbagbe rẹ ati õre gbogbo ti o ṣe fun mi loni, iwọ Ọgbẹni Ilẹpa, nitori nigbati mo de ihin ilu rẹ yi kò ye mi. Sibẹsibẹ nã pẹlu, mo ṣì ni nkan lati bẹ ọ, emi ti mo gbe ara enia wa si ilu awọn oku ko le ṣai bẹru ara mi. Jọwọ maṣai wi fun mi ọna ti ng o gbà ti nko ni fi kọlu awọn oku wọnyi, nitori nko ri wọn, awọn nikan l'o ri mi. Igbati o ba si kọ mi





ni ọna eyini tan jọwọ maṣai tun wi fun mi ọna ti ng o gbà ti ng o fi de ilu ti orukọ rẹ njẹ Ero-ẹhin nitori ibẹ ni mo mura ati lọ lati ile; ṣe iwọnyi fun mi, Ọgbẹni Ilẹpa, Olodumare yio ṣe aiye rẹ ni rere.'

"Nigbati mo wi bayi, o ni, 'Iwọ ọmọ enia, ibaṣepe o bẽre imọran lọwọ mi nipa ilu Ero-ẹhin ni emi iba wi fun ọ pe ki o má lọ, ilu iku ni; ilu arun ni; ilu wahala ni; ilu aigbadun ni; ilu ẹkun, ilu òṣé, ṣugbọn bi o ba fẹ lọ dandan ng o fi ọna ibẹ han ọ, wo iwaju rẹ ni isalẹ, ni ọkankan ibiti iroko nla wa nì, ọna ilu Ero-ẹhin ni, ibẹ ni ki o mã ba lọ.

"'Nipa awọn oku wọnyi jẹki nṣe agbara fun ọ ki o ba le ri wọn, gba eso obi yi, igbakigba ti o ba ti fi i si ẹrẹkẹ—maṣe jẹ ẹ o—gbangba ni iwọ o mã ri wọn. Obi keji ti ng o fun ọ jẹ nkan anfani fun iwọ pãpã, bi o ba ti fi i si ẹnu ẹnikẹni ko le ri ọ ni ode aiye yi, àfẹri ni.'

"Bẽ ni o fun mi ni obi meji yi, igbati mo si fi ọkan ninu wọn si ẹnu, lõtọ gbogbo awọn oku wọnni ni mo ri ṣugbọn nko mọ ẹnikẹni ninu wọn, gbogbo wọn nkọja mi nwọn ko tilẹ ṣe bi ẹnipe nwọn ri mi. Nigbati mo ti gba obi yi tan ni mo ti ki Ilẹpa, mo si wi fun u pe biotilẹjẹpe ọrọ ti o sọ nipa Ero-ẹhin buru to bẽ sibẹ mo fẹ lọ de ilu nã nitori ibẹ ni mo ti fi ọkan mu lati ile, nkan ti ọkan ba ti pinnu a mã ṣoro lati yipada; mo mura mo nlọ.

"Owurọ ọjọ keji ni mo de ilu Ero-ẹhin nkan ti oju mi si ri nibẹ pọ tobẽ ti o ṣoro lati to lẹsẹsẹ.

"Nigbati mo de ilu nã mo ba gbogbo wọn lẹnu ija nitori gẹgẹ bi aṣa ilu nã ojojumọ ọjọ aiye ni nwọn ni lati ja ni kutukutu owurọ ki nwọn to jẹun, ija ti mo sọrọ rẹ yi ki iṣe kekere rara, ẹnikẹni ti nwọn ba ri, lilù ni, riri ti nwọn si ri mi igi ni nwọn ko bò mi, nwọn

lu mi tobẹ̃ ti mo fi digbo lulẹ ti mo dákú, igbati òyì fẹ si mi ni mo si to le dide.

" Igbati mo dide tan mo mura o di ile ọba, mo fẹ lọ fi ẹjọ sùn ṣugbọn nigbati mo de ọhun ibiti nwọn ti nfẹ oyi si ọba pãpã ni mo ba a, nwọn ti lu u nwọn da a lẹsẹ ehin rẹ meji si ka.

" Kìkì oku ọmọ enia l'o wa ni igboro Ero-ẹhin, ilu ikọsilẹ ni.

" Ibiti mo ti nrin ka mo ri ọmọbinrin kan ti o ki mi mo si ro nkan ti oju mi ri fun u, on nã l'o la a ye mi pe ojojumọ ni ija ni ilu Ero-ẹhin ojojumọ si ni ole jija, o wi fun mi pe agogo mẹfa alẹ ni ole jija bẹrẹ o ni, ' Ọmọkunrin ṣe ni ki o wa ibi sa pamọ si nigbati o ba di oju alẹ nitori nwọn le bọ ṣokoto idi rẹ lọ,' Mo wi fun u pe nkò ri ibi wọ̀ si o si wi fun mi pe on o ba mi sọ fun baba on bọya nwọn le gbà mi si ile awọn.

" Lõtọ o ba baba rẹ sọ ọ nwọn si gba mi si ile wọn. Ṣugbọn nigbati mo de ọdọ baba rẹ ohun ti mo gbọ ya mi lẹnu o ki mi dãdã o ni, ' Iwọ ọmọ enia, ilu Ero-ẹhin ni iwọ wà yi, ihin ni ile Ọgbẹni Rikiṣi-g'ori-itẹ, on ni ọba wa, ilu wahala ni yi nitori ati ọwọ Eṣu ni Rikiṣi-g'ori-itẹ ti mã ngba aṣẹ, gẹgẹ bi eto ọba ilẹ yi jeki nka ofin ti a ni lati tẹle lojojumọ fun ọ:

Ekini: Bi ilẹ ba ti mọ olukuluku ni lati mã lu ẹnikeji rẹ, ija nla ni lati bẹrẹ ni ilu ẹniti kò ba ja ninu ija yi yio ri ibinu ọba.

Agogo Mẹjọ: Olukuluku enia nilati ko oku ti o ku ninu ija jọ si ẹhinkunle rẹ.

Agogo mẹsan: Akoko èpè ati ẽbu ni eyi gbogbo awọn ọmọ ilẹ yi nilati mã bu ara wọn ki nwọn si mã ṣẹ èpè ti o buru gidigidi.

Agogo mẹwa: Gbogbo ọmọ ilu nilati lọ jẹun.

Agogo Mọkanlã: Eleyi ni akoko ipade eke, gbogbo





enia nilati mã purọ, irọ ti o ṣoro lati já, akoko rikiṣi ni eyi pẹlu, ẹnikan ni lati wa ẹnikeji mọra ki nwọn pa ero bi awọn o ti ṣe sọ ẹnikẹta di ero ẹhin.

Agogo mejilã: Eleyi ni akoko igberaga fun gbogbo wa, ẹniti ko ba ni nkan nilati mã sọ pe on ni, o si nilati mã sọ pe ẹniti o ni kò ni.

Agogo kan: Akoko ofofo ni eyi, olukuluku nilati mã yọ kẹlẹkẹlẹ sọrọ ẹnikan fun ẹnikeji ki nwọn mã tu aṣiri ẹnikeji fun ẹnikẹta.

Agogo meji: Akoko irẹjẹ ni yi olukuluku nilati wa ẹnikan rẹjẹ, o si nilati kọ orukọ ẹniti on rẹjẹ silẹ fun awọn ọlọpa ti yio mã yẹ iwe irẹjẹ wo.

Agogo mẹta: Onjẹ ọsan.

Agogo mẹrin ati marun: Ipade ole jija ni eyi fun awọn ọmọ ilu, eleyi ni akoko ati ronu ile ti olukuluku mã kó.

Agogo mefa alẹ ni ole jija bẹrẹ gãn.

" ' Dajudaju iwọ o ri i pe ilu yi ki iṣe ilu ti enia ti le ṣe nkan anfani, ilu ibajẹ ni, ilu iparun si ni pẹlu nitorinã iyanju ti mo le gba ọ ni pe ki o maṣe duro pẹ nihin bi o ba ni aiye rẹ lati fi ṣe nkan.'

" Bayi ni baba ọmọ nã sọ fun mi mo si bẹrẹsi ronu ona ti ng o gba yọ.

" Nigbati o ti ndi agogo marun-abọ ni nwọn ti bẹrẹsi ti ilẹkun ati ferese ile wa nitori ole, ogoje ọna ariwo si ti ta ki ilẹ ọjọ keji to mọ, fila ti mo de wọ nu ile nã sọnu ki ilẹ to mọ nwọn si ji apoti aṣọ kan ni ile bãle wa.

" Nigbati o di ọjọ keji ti ọmọbinrin ti o mu mi lọ ibẹ lọ si odo lọ pọn omi, akoko ija wọn ti bẹrẹ nwọn lu u pa, bi mo ti yọju si ita oku rẹ ni mo ri ni ẹhinkunle.

" Ero-ẹhin jẹ ilu ti o wà leti omi okun, mo si bẹrẹsi a ọna ati wọ ọkọ ki nsalọ. Ṣugbọn ọkọ ki iduro ni

ilu nã afi bi enia ba lọ wẹ̀ ba ọkọ ti o ba nkọja lãrin
agbami.

" Nigbati o di owurọ ọjọ kan mo ṣe akiyesi ọkọ
kan ni ãrin okun mo si mura ki nba lọ ba a ṣugbọn bi mo
ti bẹ lu omi ti mo nwẹ̀ lọ ni awọn kan bẹ̀ tì mi ti nwọn
nle mi lọ, nigbati o ṣe mo mõkun lọ si isalẹ nwọn k
si ri mi mọ, nigbati mo mã yọ ibiti ọkọ wà ni mo t
yọ mo si di mọ ọ.

" Ọkọ oniṣowo ni ọkọ nã, nigbati mo si ti duro p
diẹ ninu rẹ̀, ti mo mọ diẹ ninu awọn ero ọkọ, mo wad
ibiti nwọn nlọ, nwọn sọ fun mi, mo si bẽre bi nwọn
ba le jẹ̀ki npa owo ọwọ mi pọ mọ tiwọn ki a jọ mã
ṣe òwò ki a si mã pin ere rẹ̀. Nwọn si gbà bẹ̃, mo n
owo diẹ lọwọ nigbanã, owo ti mo ri kó ninu ile iwin
" Nigbati o ṣe a de ilu kan ti nkan ibẹ pọ̀ pupọ
ọgẹdẹ wẽre ko ni iye, ọgọtã ni ẽpinni, ọgọrin ẹyin adi
ni tọrọ, àgbọn mẹwa ni ẽpinni, garawa epo pupa j
sísì a si ra gbogbo awọn nkan wọnyi a ko wọn si in
ọkọ wa, ọkọ si kun bamubamu. Ṣugbọn nkankan ṣẹl
si mi ninu ọkọ yi ti ng o sọ fun ọ iwọ ọrẹ mi, o bur
gidigidi.



# ARỌGIDIGBA TI IṢE OLORI ẸJA INU OMI.

"Bi a ti kuro ni ilu ti a ti ra nkan si ọkọ yi ni ẹfũfu bẹrẹsi fẹ, ẹfũfu nã si lagbara tobẹ̃ ti o fi jẹ wipe omi nya si inu ọkọ wa pupọpupọ, ki a má sa fa ọrọ yi gun lọ titi, atẹgun yi da oju ọkọ wa de.

"Eyiti o ya mi lẹnu ju gbogbo rẹ̀ lọ ni pe bi ọkọ wa ti da oju de ti mo ngbiyanju ati di igi rẹ̀ mu ni ẹnikan nfà mi ni ẹsẹ ni isalẹ. Nigbati o pẹ ti mo ti nja o rẹ̀ mi mo si fi ara mi silẹ fun iku. Ṣugbọn nigbati mo de inu omi lọhun ni mo ri ẹniti nfà mi nã, o gbe apoti digi nla kan lọwọ o si ti mi si inu apoti nã, on nã bọ si ibẹ pẹlu mi. Mo ri i pe igbati mo bọ sĩ inu apoti yi mo nmi dãdã mo si ri i pe ki iṣe enia ni ọkunrin ti o mu mi si inu apoti nã, o san ibantẹ, ko ni irun lori, ẽkan ọwọ rẹ̀ si gun sọbọlọ, o ni iru ni idi bi ẹja ṣugbọn o ni oju meji bi enia afi ti pe oju mejeji tobi ju ti enia lọ o si ri róbótó bi oṣupa. O ni irun gigùn ṣanranṣanran ni imu ti o fi ara we ti ẹja, ehin rẹ̀ dabi ti kiniun, o tobi o si nipọn.

" Ẹniti o mu mi yi ko fi mi silẹ bẹ̃, bi ile digi yi ti njá lọ si isalẹ omi okun, igbati o ba ṣe a fa mi l'eti, bi o ba ṣe a gba mi l'eti, bi o ba pẹ a ja mi lẽkan a si mã fẹ oju ati ehin rẹ̀ si mi a mã fi dẹruba mi. Igbati o ba ṣe a fa mi ni ete isalẹ ati ti oke a fẹrẹ fa a ja, ikarawun igbin wà ni isalẹ ile nã a si mã mu iwọnyi a mã fi họ mi lara tobẹ̃ ti gbogbo ara mi bo féléfélé; nigbati o pẹ mo bẹrẹsi bẹ̀ ẹ, mo nra ọwọ si i ṣugbọn ko tilẹ wo mi loju rara, o nfi iya jẹ mi bi a ti nlọ.

" Nigbati o ṣe ile nã kanlẹ, mo si ri i o jade, o si ti ile nã si iwaju, lẹhinnã o fa mi jade ninu ile nã, nigbati

mo si wo ẹhin mo ri i pe okuta ti o nipọn ti o si tobi ti o dabi digi nla kan ti se omi okun mọ apakan, ori ilẹ ti o jẹ kiki yanrin funfun ni mo wà.

"Nigbati mo wo iwaju mi mo ri ile ti o tobi ti o si ni ẹwa pupọ iwaju ile nã kun fun eweko kekeke ti o dudu mirinmirin ti nwọn gẽ mọlẹ ti o ba ara wọn dọgba ti o si mu ki agbegbe nã dabi ile ọba pataki kan. Ọna kan wà ni iwaju mi, ibiti ọkunrin nã nmu mi lọ, o jẹ ọna titobi o kun fun yanrin funfun, ṣugbọn nigbati a rin bi ãdọta ẹsẹ bata mo ri òpó meji ti nwọn rì mọlẹ ọkõkan ni apa ọtun ati osi, nwọn gbe igi nla kan le ori awọn mejeji, ni ẹgbẹ igi ti nwọn gbe le awọn opo meji yi lori mo ri akọle yi nibẹ: 'ẸLEYI NI AFIN ARỌ-GÌDÌGBÀ TI IṢE OLORI ẸJA INU OMI, ỌDUN ARỌ-GÌDÌGBÀ SUNMỌ ETILE KI AWỌN ẸBỌRA ISALẸ IBU OMI OKUN LỌ MÃ WA AWỌN ỌMỌ ENIA WA KI NWỌN FI ṢE ARIYA ỌDUN ỌBA.'

"Igbati mo ti kuro ninu ile kekere ti o gbe mi de isalẹ ni iwin nã ti kó mi lọwọ mejeji si ẹhin ti o fun mi ni okun danindanin, ọwọ osi l'o si fi tì mi ni ipakọ ti o ntãri mi ba oju ọna lọ. Igbati mo ti de ibi opo meji yi ni mo ti bẹrẹsi ri awọn iwin bi eyiti o mu mi yi ti nwọn duro si ẹba ọna lọ, awọn wọnni ni ọlọpa ibẹ. Nigbati a rin diẹ a tubọ sunmọ ile ti mo ti nwo niwaju mo si ri i pe ãfin nla ni. A wọ ãfin nã, ẹwa rẹ si pọ gidigidi, bi a ti nrin lati apakan de ikeji ni a nri ohun ọṣọ ti nwọn fi gõlu ṣe. Nigbati o ṣe a ja si ibiti o tẹju pẹrẹsẹ kan bayi ninu ile nã nwọn si to oriṣiriṣi okuta si ita ibẹ gbogbo rẹ nkọ mọ̀nà bi imọ̀nàmọ́ná oju ọrun. Nigbati mo wo opin ita pẹrẹsẹ nã ni apa oke mo ri ẹnikan ti o joko bi ọba. Àrọ̀-gìdìgbà ni eyini. Ko tilẹ jọ ẹja rara, o dabi ọmọbinrin o si di





irun ori rẹ winnikin o da aṣọ àrán ti àwọ̀ rẹ̀ dabi aṣọ alaro ti nwọn ṣẹṣẹ rẹ bora, nwọn si fi àrán pupa bo ẹgbẹ ẹgiri lẹhin rẹ̀, àtẹ̀gùn kekeke kan bayi ni nwọn fi okuta ṣe lati isalẹ lọ de oke ibiti Àrọ̀-gìdìgbà wà, gbogbo ayika ibẹ si ni ẹwa gidigidi.

"Nigbati o ri wa o dide, igbati o si dide yi ni mo to wa ri i pe ìrù wà ni idi rẹ̀ bi ti ẹja.

"Bi a ti yọ si i ni o kigbe si iwin ti o nmu mi ' ọ ni, 'Mu u duro, mu u duro lọhun nì, ọmọ enia ko gbọdọ de sakani mi, kini ọmọ enia jẹ? O jẹ akẽkẽ ti o wà fun ipalara, paramọlẹ labẹ koriko, ẹni ibanujẹ fun awọn ẹda alãye, enia duro bi ẹniti o fi oju ida rẹ bo ilẹ, o nlo ọla ti Olodumare fi fun u rẹ́derẹ̀de. Tani o yin, ẹnyin enia? Ki si ni ilo yin si awọn ẹja? Ẹja kekere, ọta enia; titobi, ọta enia; bi enia ba tilẹ pa ẹja ti nwọn njẹ ẹja a kò ba ti binu ju bẽ lọ, nitori ola ti Ẹlẹda fun wọn ni, ṣugbọn iya ti ogunlọgọ wọn njẹ ẹja ki nwọn to pa ẹja lodi si ilana ti Ẹlẹda ṣe fun wọn. Nitorinã, emi ni yi, emi Arọ-gidigba ti iṣe olori ẹja inu omi, oni ni aiye tirẹ pin, pipa ni ng o pa ọ. Iku ti o ba fẹ ku ni mo fẹ ki o yàn, yala ki npa ọ bayi ni, tabi ki nṣe ọ bi ẹ ti nṣe awọn ẹja ki nfun ọ ni nkan ti yio pa ọ, ti yio mã pa ọ diẹdiẹ, eyini ni pe ki fun ọ ni iṣẹ lile ṣe. Mọ daju pe ko si ọna ati là fun ọ, mi ni iṣe alakoso awọn nkan ti ngbe inu omi, erinmi, wọn ejo pataki, ati awọn ẹranko nla inu omi, Olokun kanṣọṣọ ni o jẹ aṣãju mi ninu awọn ẹbọra.

"Bayi ni ẹda buruku yi wi emi nã si fun u ni esi o ni, 'Kabiyesi, biotilẹjẹpe inu nbi yin sibẹ mo lati kọ sọ bi inu mi ti dun to lati mọ yin loni, ẹnyin ẹ wa gẹgẹ bi olori ẹja inu omi. Mo si fẹ ki ẹ mọ bi ekute ko ti lagbara niwaju ologbo bẽ nã ni nko gbara niwaju yin, bi agbọnrin ko si ti le ṣe nkankan

niwaju kiniun ni nko le ṣe nkan. Ṣugbọn nko fẹ ki ẹ ni ero pe gbogbo ọmọ araiye ni o nṣe ibi si ẹja. Lõtọ Olodumare fi oye jinki awọn ọmọ enia, onirũru si ni gbogbo wọn. Emi ti ẹ mu yi ko ṣe ibi si awọn ọmọ ẹja ri, nkò si ba erinmi ni ija pọ, bẽni awọn jomijoke ko ni ẹjọ kan pẹlu mi. Bi ẹ ba pinnu ati pa mi, ẹ maṣe pa mi loni, ṣugbọn ki ẹ kuku fun mi ni iṣẹ ti ng o ṣe ti ng o ku le lori. Kabiyesi.'

" Nigbati mo sọ bayi o ni on fun mi laye ati ṣiṣẹ ki nku le e lori ṣugbọn iṣẹ ti o kọ fun mi ṣoro tobẽ ti nko le ni ero meji ju pe ojiji iku nrọdẹdẹ lori mi: O ni, 'Iṣẹ ti o nilati ṣe fun mi ni eyi, ki ilẹ ọla to ṣu o ni lati mọ ile kan ti o ni iyãra mejilã ti o si ga ni ẹsẹ bata mejilã si iwaju ile mi yi, bi o ko ba le ṣe e ng o pa ọ jẹ lalẹ ọla.'

" O ko ri i pe iku gãn ni eyi jẹ fun mi, ọrẹ mi? Ẹkun ni mo bu si mo si bẹrẹsi bẹ ẹ ki ó má ṣe bẽ ṣugbọn ko tilẹ ṣe bi ẹnipe on ri mi, o ni ki nwọn tu okun apa mi ki nwọn mu mi lọ si ile iya on ki nlọ sun nibẹ mọju.

" Nwọn fun mi ni iyãra kan ni ile nã nwọn si fun mi ni onjẹ, mo jẹ ẹ mo si fi ẹhin le ilẹ. Bi mo ti sun tan ni mo ri ti ẹnikan fi ọwọ kàn mi ti o si pe mi ni orukọ mi o ni, 'Ireke-onibudo, tanna.' Eleyi yà mi lẹnu mo si tanna; nigbati mo mã wo o, o di iya mi ti o ti ku, mo si mura ki ndi mọ ọ o ni nko gbọdọ ṣe bẽ. Mo pa gũru si i ki ndi i mu ṣugbọn ofo ni mo di mu. Lẹhin eyi o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni:

" 'Ọmọ mi, Ireke-onibudo, mo ri ìyà ti o ti njẹ ọ lati igbati mo ti fi aiye silẹ mo si fẹ ki o mọ pe o ko ni ṣegbe si inu ìyà wọnyi, ni igbẹhin aiye rẹ ayọ ni yio jẹ ipin rẹ. Maṣe bẹru Arọ-gidigba, ipa rẹ kò le ka





ọ, awọn ogun ọrun nbọ lẹhin mi nisisiyi nwọn o si ṣe iṣẹ ti o fun ọ ki ilẹ to mọ.'

" Bi iya mi ti wi bẽ tan o fi ika la ilẹ ni origun mẹrẹrin iyãra ti mo wà, were ilẹ si bẹrẹsi là, awọn ogun ọrun gbogbo si bẹrẹsi jade pẹlu ọkọ ati ada, pẹlu akengbe ati garawa. Nwọn bẹrẹsi ṣe iṣẹ, nigbati o si kù diẹ ki ilẹ mọ nwọn pari ile ti Àrọ-gìdìgbà gbe fun mi.

" Nigbati o di owurọ ọjọ keji ẹru ba Arọ-gidigba pãpã nitori ko ye e bi mo ti ṣe le ṣe e.

" Lẹhin eyi o fun mi ni iṣẹ miran ti o ṣoro fun ọmọ enia lati ṣe, o ni ki nlọ ṣan oko kan si agbala on ki ngbin iṣu si i ki iṣu nã yọ ewe lọjọ ti mo ba gbin i ki o si ta ati wipe laijẹ pe mo ṣe eyi ni ọjọ keji ori mi ki yio sun lọrùn mi.

" Nigbati mo gbọ bayi mo wọ inu ile mi lọ mo si bẹrẹsi sọkun mo nke pe iya mi mo ni, 'Iya mi o, iya mi olododo, iya mi alagbara, iya mi ode ọrun, iya mi ọlọgbọn, iya mi oloyelori, iya ti o ju iya lọ, iya ti o ni ifẹ ọmọ de gongo, iya mi aiye, iya mi ọrun, iya ti o fẹran ile, iya ti o fẹran ọna, iya mi ti mbẹ ni ipo oku ti nṣe ẹgbẹ awọn alagbara ode ọrun, awọn ọmọ alade, awọn ti o ni gbongbo iṣegun lọwọ, awọn ti o ju ẹda iyoku lọ, iya mi O ! — ! — ! — iya mi O ! — ! — ! — iya mi O ! — ! — ! —.'

" Bayi ni mo ke, iya mi nã si gbọ, o jade lati inu ilẹ wa, o mu ẹnikan pẹlu ara rẹ. Nigbati mo sọ fun u o ni ko ṣoro afi ti iṣu ti o ni lati hù lõjọ, ẹniti o ba a wa si wi fun u pe iṣu ti yio hu lõjọ wà lode ọrun ati wipe ibiti o wa lọhun pãpã jina afi bi on ba nilati fo lọ. Iya mi wi fun u ki o jọwọ yara lọ, were o fi ẹsẹ lu ilẹ, ilẹ si là si meji were o wọ inu rẹ lọ, o fò ba ibẹ lọ, kò si pẹ nigbati o ko iṣu nã de, kò ju kekeke lọ, ko tilẹ ju ẹyọ ekurọ kan lọ ni titobi ọkọkan.

"Lẹhin eyi iya mi tun pe awọn ogun ọrun nwọn si jade lati inu ilẹ pẹlu ada ati ãke on ọkọ. Were nwọn pari iṣẹ nã, iṣu hù ni werewere o ta, gbogbo ebè si ti fọ kãkiri oko. Nigbati o di akukọ iya mi ati awọn ogun ọrun wọnni lọ si ode ọrun.

"Mo ji nigbati õrun bẹrẹsi yọ bi mo si ti run orin ti mo bọ oju mi tan ni mo lọ si ọdọ Àrọ̀-gìdìgbà mo sọ fun u pe mo ti pari iṣẹ ti o ni ki nṣe. Nigbati mo wi bẽ, o dide o lọ wo o, nigbati o ri i o kigbe nla tobẽ ti o jẹ pe gbogbo awọn ijoye rẹ l'o gbọ ti ilẹ si mì tìti nitori ẹru bẹrẹsi ba a bọya mo le ri ẹhin on pãpã dipo ki on ri ẹhin mi. Ọrọ nã ba a lẹru tobẽ ti o fi jẹ pe ko le bu omi si ara fun wakati mẹfa lọjọ nã bẽni wakati kọkan ni o mã nbu omi si ara titi ọjọ aiye rẹ.

"Lẹhin eyi o wa sọ fun mi pe on o jẹki nmã lọ bi mo ba le ṣe iṣẹ kan ti o kù ti on fẹ fun mi. O ni ẹranko kan wà ti orukọ rẹ njẹ ewurẹ-ibẹru ti o mã nyọ awọn lẹnu lagbegbe ibẹ, ati ọdọ eṣu ni ewurẹ-ibẹru ti mã nwa, wipe on si nfẹ ki nba ẹranko nã jà, bi mo ba le ṣẹgun rẹ ki nmã lọ. O da ọjọ meje ti ija nã yio bẹrẹ ṣugbọn lãrin ọjọ meje nã ile iya Arọ-gidigba ni ng o mã gbe, bẽni ajẹ ni iya nã o si ti wi fun u ki o pa mi jẹ ki o to di ọjọ ija nã, mo gbọ nigbati o nsọ fun u ṣugbọn ko mọ pe mo gbọ. Iyãra mi dojukọ agbala iya Àrọ̀-gìdìgbà mo si ti nṣe akiyesi awọn ikoko mẹfa nla kan nibẹ lati igbati mo ti de ibẹ pe abami ni wọn. Nigbati o di alẹ ọjọ ti olori awọn ẹja sọrọ ija yi fun mi, mo ri nkankan, mo fi ẹhin le ilẹ ninu iyãra mi mo si nwo obinrin ajẹ yi o wọ inu ọkan ninu awọn ikoko wọnni lọ, lẹhin ti o ṣe eyi tan mo ri ejo nla kan o ti inu ikoko nã jade ; ejo yi rin kiri titi ṣugbọn ko wa si ọdọ mi, lẹhinnã ni o tun wọ ikoko ti o sunmọ mi ju, nigbati o si mã jade o di iya Àrọ̀-gìdìgbà bi o ti ri tẹlẹ. Lẹhin eyi iya nã tun wọ inu ikoko miran, nigbati o si ṣe bẽ mo ri, kiniun kan jade lati inu ikoko nã, igbati o tun ṣe kiniun yi wọ inu ikoko ti o wà lẹba ọdọ mi o tun di iya Àrọ̀-gìdìgbà pada, bẽ ni obinrin yi ndan awọn ikoko wọnyi wo ti o ndi onirũru nkan ṣugbọn inu ikoko ti ẹba ọdọ mi ni o nwọ ki o to yipada, gbogbo bi o ti nṣe ni mo nwo nitori oṣupa wà lakoko nã.





"Nigbati o di alẹ ọjọ keji mo mu obi ti Ilẹpa fun mi ni ilu awọn oku mo fi si ẹnu ẹnikẹni ko si le ri mi, mo gbe ẹni ni ibusun mi mo jade mo tẹ ẹ si abẹ igi kan ni ita. Lọjọ nã obinrin nã fẹ pa mi gãn ni, oju mi bayi l'o ṣe yipada ti o di ejo ti o wọ iyãra mi lọ ti o nwa mi kiri, o wa mi titi ko ri mi. Nigbati o jade ninu iyãra mi tan mo wọ ibẹ pada, nigbati ilẹ si mọ mo mu obi kuro lẹnu, o wo mi titi ko mọ eyiti on iba ṣe.

"Bayi ni mo bẹrẹsi sa pamọ ni alãlẹ ti on nã nwa mi kiri ti ko le mu mi titi ọjọ kẹfa fi pe ti mo nilati ba ewurẹ-ibẹru ja bi ilẹ ba mọ. Loru ọjọ yi o yipada o di ejo, nigbati mo si ri i pe o ṣe bẽ tan mo yi ikoko agbo ti o mã npada si ki o to tun di bi o ti wà tẹlẹ danu. O wa aye titi ati yipada ko le ṣe e mọ nigbati ilẹ mọ o fà wọ inu igbo lọ. Ọmọ rẹ bẹrẹsi wa a kiri ṣugbọn ko ri i, o bẽre lọwọ mi mo si wi fun u pe emi nã ko ri i.

"Bi akukọ ti nkọ lọjọ nã ni iya mi de o si mu ida idẹ kan fun mi, o dahun o ni, 'Ireke-onibudo, mura bi ọkunrin loni o, ṣe bi akọni ọkunrin, jẹki ọkan rẹ le bi okuta ti ẹnikẹni ko le bori, ranti, Ireke-onibudo, ewurẹ-ibẹru ki iṣe ewurẹ aiye, ohun ọsin olori ibajẹ ni, Eṣu ọba ilu ọrun Apadi ni olotu rẹ, iwo mọkanle-lọgọta ni mbẹ lori ewurẹ nã, nigbati o ba yọ lọkankan gbogbo iwo wọnyi ni yio gbina, bi ina nã si kan omi ki iku, yio tubọ mã jo ni. Ṣugbọn, gbà, fi ororo yi pa ara ki o si duro de e, ina ara rẹ kò ni jo ọ. Bi ó ba de

ba a ja ki o si wa aye ki ida yi kan a lara ki o kan ẹjẹ rẹ̀, bi o ba le rọju ṣe eyi iwọ yio bori ẹranko nã. Ṣugbọn bi ó ba di pe ipa rẹ ko ka a mu obi ti o gba ni ilu oku ki o fi i si ẹnu ki nwọn má ba le ri ọ. Ẹlẹda rẹ yio duro ti ọ lọjọ oni o.'

"Ọrọ yi ni iya mi sọ fun mi lẹhinnã o ba inu iho ilẹ lọ.

"Nigbati o di agogo kan, Àrọ̀-gidigba ke si mi pe o ya ki a lọ si ibi ija nã mo si mura, on nlọ niwaju emi nbọ lẹhin, o mu aguntan kan lọwọ.

"Nigbati o ṣe a de ibi ti nwọn kọ òkìtì kan bayi si, gbogbo ibẹ tẹju lọ pẹrẹsẹ, ibẹ to ogun iṣẹju ni òró ati ogun iṣẹju ni ìbú, gbogbo ibẹ jẹ yanrin.

"Nigbati a de idi òkìtì yi Àrọ̀-gìdìgbà pa aguntan ti o mu lọwọ o wa iho lori okiti nã o da ẹjẹ aguntan nã si i. Lẹhin eyi o mu màrìwò ọpẹ o na a mọ ilẹ ni ẽmẹta, ni ẹlẽkẹta o kigbe nla o pe ewurẹ-ibẹru. Were ilẹ bẹrẹsi là kãkiri agbegbe ẽfin si nti inu ilẹ jade, ẽfin nã pọ tobẽ ti a fẹrẹ má ri ara wa mọ. Nigbati o ṣe ẽfin bẹrẹsi dawọ duro, mo si wo ọkankan bayi mo ri ẹranko nã pẹlu ọgọta iwo ti ntanna ṣẹṣẹ, o sare o nbọ lọdọ wa, ire rẹ̀ nã pọ tobẽ ti Àrọ̀-gìdìgbà pãpã fi salọ. Nigbati o ku diẹ ki ẹranko nã de ọdọ mi o fo soke lati fi ìwo rẹ̀ gún mi, ṣugbọn mo ti yara fi obi nì si ẹnu ki o to de ọdọ mi ko si ri mi mọ. Lẹhin eyi mo rọra bẹrẹ si abẹ ibiti ẹran nã duro si mo di i ni ọrun mu, gbogbo ina ori rẹ̀ bò mi ṣugbọn ko jo mi, o si bẹrẹsi fi iwo ori rẹ̀ gun mi titi mo fi ṣubu nitori o ri mi nigbanã igbati mo ti bọ si abẹ rẹ̀ ni mo ti mu obi kuro lẹnu. Igbati mo ṣubu on nã ṣubu le mi, mo yi i kuro lori mi, mo yi le e, on nã si tun yi mi a bẹrẹsi yi bẽ lọ. Nigbati o ṣe iya mi di ẹiyẹ o fo wa si ọdọ mi, o ran mi leti ida ọwọ mi. Igbanã ni mo rọra wa ọgbọn mo fi





ọwọ kan fa ida yọ mo di i ni irungbọn mu mo fi ida nã bọ ọ ni ọna ọfun oro rẹ̀ si mu u lẹsẹkannã o digbo lulẹ, ina ori rẹ̀ si bẹrẹsi ku, on nã pãpã njà ni ilẹ, igbati o ṣe ko le jà mọ, o ku.

"Ṣugbọn ibanujẹ nla ni eleyi jẹ fun Àrọ̀-gìdìgbà, nitori apa rẹ̀ kò ka mi mọ, igbẹhin on pãpã si sunmọ eti ilẹ, o ronu lọkan ara rẹ̀ ko mọ nkan ti on tun le fi mi ṣe.

"Bi mo ti wi ṣãju, igbẹhin on pãpã sunmọ etile: nigbati o di oru ni iya mi ko awọn ogun ọrun de ti a bẹrẹsi gbọ ibọn ti Àrọ̀-gidigba nkigbe lohun rara, nigbati ilẹ mọ gbogbo awọn ti o wà ni ãfin ti ku tan ẹwọn kan si so Àrọ̀-gìdìgbà pãpã mọ ofũrufu, o ku.

"Igbati o si ṣe ni iya mi jade si mi o mu mi wọ iyãra Arọ-gidigba lọ, iyalẹnu l'o si jẹ nigbati mo de ọhun ti mo ba ogunlọgọ nkan iyebiye gbogbo, a de iyãra kan a si ri ogunlọgọ ikoko idẹ inu eyiti nwọn ko gõlu, diamondi ati awọn okuta olowo iyebiye miran si. Mo mu diẹ ninu wọn, nko lè rù wọn tan nitori nwọn wuwo ṣugbọn eyiti mo mu to sọ mi di olowo fun iyoku aiye mi.

"Nigbati a jade ninu ile nã iya mi wi fun mi pe o to akoko ki nwa kuro ni ibẹ ki njade si gbangba, mo di ẹru mi, emi ati iya mi jọ di i nã ni, nigbati a di i tan o ni ki ntẹle on mo si tẹle e, nigbati a rin diẹ o fi ọna ibiti ng o mã ba lọ han mi, lẹhinnã o wi fun mi pe on mã pinya pẹlu mi, o fi ẹsẹ lu ilẹ, ilẹ là labẹ ẹsẹ rẹ̀, iya mi si bẹrẹsi wọ inu ilẹ lọ, o nki mi bi o ti nlọ, omije ti o dabi ẹjẹ si nti oju rẹ̀ jade, emi nã sọkun titi, oju mi fẹrẹ yọ.

"Nigbati iya mi lọ tan mo fi ori le ọna ibiti o fihan mi mo nlọ. Mo rin diẹ ebi si npa mi nigbati o ṣe mo de orita kan mo si ba ọgẹdẹ pupa nibẹ, mo kigbe titi

ki ẹniti nta ọgẹdẹ nã da mi lohun ṣugbọn nkò gbọ ohun kan, mo si wo ọgẹdẹ nã ko ju ti ṣile kan lọ mo ba fi ṣile kan silẹ mo ko ogẹdẹ lọ.

" Ọgẹdẹ yi ni mo jẹ titi ilẹ fi ṣu lọjọ nã nko si de ibikan ti mo le wipe mo mọ titi ilẹ fi ṣu ti mo ni lati sun labẹ igi ni ãrin igbo.

" Lọjọ keji nigbati mo ji ebi npa mi ọgẹdẹ ko si wù mi ijẹ, ọjọ nã ni mo mọ pe iyi owo wà lọtọ̀, iyi onjẹ si wà lọtọ̀ pẹlu, mo gbe owo le ori ṣugbọn nkò ri nkan fi rà bẹ̃ni nko le sọ owo di onjẹ. Nigbati o ṣe mo de idi ọpẹ kan mo ri ẹyìn ti o wọ̀ silẹ, mo sọkalẹ mo bẹrẹsi he e jẹ. Ibiti mo ti nṣe eyi ni mo ri ẹiyẹ ẹlulu kan ti o nfo kọja leti ilẹ mo si sọ oko si i ; oko mi ba a mo si pa a, on ni mo sun jẹ lọjọ nã titi ilẹ tun fi ṣu mi si inu igbo.

" Nigbati o wa di owurọ ọjọ kẹta ni nkan bi agogo mẹsan mo pade obinrin kan ti o gbe agbado tutu ti nwọn ti se ti o si gbona yaya kan ti o ntà a mo yọ pupọ nitori eleyi fihan mi pe mo nsunmọ ilu kan ati pãpã pe mo le ra eleyi jẹ. Mo ra agbado nã mo si tun ra awusa pẹlu, mo gbe ẹru mi sọ kalẹ si oju ọna mo jẹun. Ibiti mo ti jẹun nã jẹ ibiti omi wà mo si mu omi le ori agbado mi.

"Nigbati mo jẹun tan mo gbe ẹru mi mo nlọ. Bi mo ti nsunmọ ilu nã ni mo bẹrẹsi gbọ ariwo, igbe ẹkun ọpọlọpọ enia, nigbati mo si mã yọ si ibẹ mo ba ọpọlọpọ ero ti nwọn pe jọ lọkunrin lobinrin mo si nwo ọba ilu nã, o joko si ọ̀kánkán awọn ọlọpa ibẹ si mu mi lọ si ọdọ rẹ. Mo de ibẹ mo ki i, ' Kabiyesi ' ko le da mi lohun kan rara, ẹkun ni o nsun ti omi rẹ aṣọ rẹ gbẹdẹ-gbẹdẹ. Nigbati mo bẽre lọwọ ẹnikan bayi bi o ti ri ti gbogbo nkan fi ri bẹ̃, o mu mi lọ si ibi iwaju diẹ bayi, nigbati mo si mã de ibẹ mo ba arẹwa wunndia kan ti





nwọn fi okùn dè mọ ilẹ, ti nwọn fun ni okùn danindanin. Ọkunrin nã wi fun mi pe ọmọ ọba ni, ati pe on ni o npa ọba l'ẹkun nitori ọjọ nã ni ọjọ iku ọmọ nã.

" Mo wadi bi o ti ṣe ri bẹ̃ o si da mi lohun o wipe : ' Ilu ti iwọ wà yi ni ilu ti orukọ rẹ̀ njẹ Alupayida ti o jẹ ilu ibanujẹ gidigidi. Apanirun ejo kan ti imã fò lofũrufu ti mã nyọ awọn ara ilu yi lẹnu lati ibẹrẹ aiye, a mã fò lati oju ọrun wa ba awọn ara ilu ni, ṣugbọn lọdun yi, awọn babalawo ati Adahunsẹ gbogbo wadi ọran nã nwọn si wipe afi bi ọba ba fi ọmọ rẹ̀ obinrin yi rubọ lọjọ oni ni apanirun ejo nã ko fi ni wa mọ. Laipẹ yi ni ejo nã nbọ lati ọrun yio si pa ọmọ yi jẹ.'

" Ọrọ yi yà mi lẹnu pupọ o si bà mi lẹ̀ru pẹlu nitori nko iti iri ọmọbinrin ti o dara bi ọmọbinrin yi lati ọjọ ti mo ti de aiye. Ko dudu pupọ ko si pupa pupọ, o pupa fẹ̃rẹ bayi ni, ko sanra pupọ ko si tẽrẹ pupọ, ara rẹ̀ tutu o ndan o si fa ni mọra, ẹyinloju rẹ̀ mọlẹ kedere bi ẹyinloju ọmọde, irun diẹ ti o si hù si ipenpeju rẹ̀ bayi dudu, o ri tẽrẹ, o si dabi igbati oṣupa ba ṣẹṣẹ le si oju ọrun. Ehin ẹnu rẹ̀ ri wẽrẹ, o funfun bi ehin aja, ori gbogbo ẹhin nã si dọgba lọ, ọkan kò tase ekeji, ete rẹ̀ mọ ni ìwọ̀ntúnwọ̀nsí ko nipọn pupọ, ko fẹlẹ pupọ, ko dudu rekọja, ko pupa tayọ, o ba ẹnu mu. Ahọn rẹ̀ pupa ko si ni ẽri kanṣoṣo, irun ori rẹ̀ dudu o si ndan, bẹ̃ ni o si di i wìnnìkìn winnikin.

" Nigbati mo ri i ọkan mi gbọgbẹ mo si wi fun ọba wipe ng o ba ejo nã ja ng o si ṣẹgun rẹ̀. Ọba kò gbà bẹ̃ o ni ki nmá ṣe bẹ̃, nitoripe, lọna kini, nko le ṣẹgun ejo nã, ati, lọna keji, ejo nã yio fi oju gbogbo ara ilu ri nkan lẹhin ija mi. Emi nã gbọ ọrọ ọba ni ṣugbọn nko gba bẹ̃, ibiti mo si ti nba ọba jiyan ni ariwo ta pe ejo nã nfo bọ ni awọsanmọ. Were ọba dide o nwo ohun ti yio de ba ọmọ on, emi nã si ti fa ida mi yọ, ida ti




"Mo di i ni ọrun mu."





iya mi mu fun mi lati isa oku pe ki nfi ba ewurẹ-ibẹru ja, mo fa a yọ mo duro ti ọmọbinrin nã, ejo yi njá bọ lọdọ wa.

"Bi o ti njá bọ tagbaratagbara lati gbe ọmọbinrin nã mo di i ni ọrun mu, were o fi ọmọbinrin yi silẹ o kọju si mi, o fi ori sọ mi ni igba aiya mo si ta gẽgẽ lọ si iwaju, lẹhinnã ejo buruku yi lọ mọ mi bi igbati itàkùn ba lọ mọ igi oko, o lọ mọ mi ni idi o si ká wé mi lara lati idi mi de ọrun, lẹhin eyi o nfi iru rẹ nà mi, o nà mi tobẽ ti mo fi ṣubu ti emi ati on nyi lọ gbirigbiri. Ni akoko yi ni mo ri aye di ida mi mu, mo fà a yọ ninu àkọ mo fi ṣonṣo ori rẹ gun u ni inu, ida nã wọle si i lara o tu kuro lara mi o si na ọrun ati idaji ara rẹ si oke, o ke bi kiniun, oró ida yi mu u, o tun gbe ọrun le ilẹ o si nfi ori gbe ipanti ni ilẹ kiri bi igbati pẹpẹiyẹ ba nfi ẹnu wa onjẹ leti odò, igbayi ni emi nã wa tun di ada mi mu, mo fi ọwọ mejeji gbe e soke mo ṣa a mọ ọ ni ọrun diẹ l'o si ku ki nbẹ ẹ ja, bayi ni mo ri ẹhin apanirun ejo ti nfo lofũrufu, ti o npa awọn ọmọ ọlọmọ jẹ.

## IGBESI AIYE MI NI ILU ÀLÚPÀYÍDÀ.

"Nko le rohin tan bi inu awọn ara ilu Àlúpàyídà ti dun to nigbati mo ṣẹgun ejo yi, ariwo sọ kakiri ilu lọ, nwọn si bẹrẹsi fọn ipe nwọn nlu ilu, olukuluku njo, ọba pãpã fi ijo si i o si wi fun awọn gende gbogbo ki nwọn gbe mi le ejika ki nwọn gbe mi yi ilu nã kiri.

"Ọmọ ọba obinrin ti mo si gbala nã wa si ọdọ mi, o kunlẹ o ki mi, ṣugbọn nko fẹ ki o fi orunkun rẹ kunlẹ rara, o ti lẹwa jù loju mi, nigbati o si bu si ẹrin ehin rẹ funfun bi ẹgbọn owu ọkan mi si tubọ balẹ wipe ẹni rere ni mo yọ ninu wahala ti mo gbà lọwọ iku, nitori ko si nkan ti o le fun enia ni ayọ bi pe ki oluwarẹ ṣe õre fun ọmọnikeji rẹ.

"Ni owurọ ọjọ keji ọba ranṣẹ si mi ki nwa mo si lọ. Nigbati mo de ọhun o bẽre orukọ mi, nigbati mo si wi fun u tan o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni, 'Ireke-onibudo, aiye rẹ o dara, aiye rẹ o dara, nkan rẹ ko ni bajẹ loju rẹ, bi kiniun ti ilagbara lãrin awọn ẹranko ni Olodumare o fun ọ lagbara lãrin awọn ọmọ enia, ọwọ araiye ko ni ka ọ, o ko ni wọ ẹwọn eṣu, gbigbega ni gbogbo enia o si mã gbe ọ ga, o ṣe e o, o ṣe e o, o ṣe e o, o ṣe e pupọ gãn ni, nko fẹ ki o kuro ni ilu yi mọ, mo fẹ lati fi ọ joye, mo fẹ ki o jẹ igba keji mi. Mo si fẹ lati fun ọ l'ọmọ pẹlu, mo fẹ ki o tun jẹ àna mi. Eyikeyi ti o ba wù ọ ninu awọn ọmọ mi ni ki o wi fun mi nigbati o ba tubọ nmọ wọn, ng o si fi fun ọ. Gbogbo ãfin yi, emi ni mo ni i, mo si tun ni ile si igboro, ng o fun ọ ni ọkan ninu awọn ile mi igboro ki o mã gbe ibẹ, igbati o ba si ni iyawo ibẹ ni ki o mu iyawo rẹ lọ, mo dupẹ pupọ, Ireke-onibudo, nkan ti mo pe ọ si ni eyi o.'





"Bayi ni ọba sọ fun mi ẹnu si yà mi pupọ, nko tilẹ mọ eyiti nbá sọ. Mo dọbalẹ gbalaja mo ku erupẹ le ori mi mo ni, 'Kabiyesi, alaṣẹ, ekeji oriṣa, nko tilẹ mọ nkan ti emi ba wi lati fi dupẹ lọwọ yin fun ọrọ pataki wọnyi, ki iṣe agbara mi ni mo fi ṣe ohun ti mo ṣe, Olodumare l'o kàdárà rẹ̀ mọ mi. Gbogbo nkan ti ẹ sọ ye mi porogodo, ṣugbọn mo ro pe ko ni bi yin ninu bi mo ba wipe nko rò pe mo yẹ ni Ẹniti iba joye ni ilẹ yi, kini mo ni. Nko ni nkankan, nko ni ẹnikẹni ninu aiye, ọmọ alainibaba ni mi bi mo ti duro yi, alaini iya si ni mi pẹlu, nitorinã, nko ro pe o yẹ ki ẹ fi mi joye. Ṣugbọn nipa wipe ki nmã gbe ilu yi o wu mi ki nṣe bẽ nitori mo le kọrin nihin pe tani npe awa ko ni baba, kai a ni baba, ọba Alupayida baba wa, kai a ni baba. Bi ẹ ba si ni ero ati fun mi ni ọmọ, Kabiyesi, nkò lè kọ, nko kuku ti il' obinrin, ng o jẹki ẹ mã gbọ bi ọrọ mi ba ti nlọ si nipa obinrin fifẹ Kabiyesi.'

"Bayi ni mo fun ọba ni esi, lẹhinnã o gbe ẹkọ ati ọbẹ ata fun mi, nwọn ti din ata nã pẹlu tòlótòló, ororo ni nwọn si fi se e. Nigbati mo jẹun tan o ke si iyawo rẹ̀ kan o wipe ki o fun mi ni igo ọti kan, mo gba a mo mu u wa si ile mi. Ṣugbọn nigbati mo mã jade ni ãfin ọba ke si ọmọ rẹ̀ obinrin ti mo gba kuro lọwọ ejo apanirun o ni, 'Ifẹpade o, o kò ni wa dupẹ lọwọ Ireke-onibudo?' Igba yi ni mo to mọ orukọ ọmọbinrin nã; on nã wa o rẹrin o ki mi o si ntiju bi o ti nṣe, emi nã nsọrọ akin lẹnu mo ni, 'Alakọri ejo nã fẹ ṣe ijamba ni, kò mọ pe ọjọ iku ti on pãpã ti pe.' Ọmọ nã sìn mi jade ni ãfin, lẹhinnã mo ni ki o pada o si ṣe bẽ ṣugbọn o ni ki nmã reti onisẹ on ni aipẹ.

"Bayi ni mo wa si ile ibiti mo wọ̀ si ni ilu nã pẹlu ayọ lọkan mi pe mo di enia pataki lọwọ ọba.

"Nigbati o di irọlẹ́ mo ri ọmọbinrin meji, nwọn ro

aṣọ dãdã, nwọn si gbe onjẹ le ori nwọn wọ ile mi. Nigbati nwọn sọ ẹru ori wọn kalẹ nwọn kunlẹ ki mi nwọn ni ọmọ ọba ni ki awọn gbe onjẹ nã fun mi nwọn si fi iwe kan fun mi lati ọdọ rẹ. Ohun ti o wa ninu iwe nã ni yi:

'Ọjọ Kẹwa Oṣu Kejilã Ni Ẹdẹgbẹwa Ọdun O le Mẹrindiladọta Lẹhin Iku Oluwa Wa,

Ireke-onibudo mi ọwọn,

Nko gbọdọ ṣai jẹki ẹ mọ bi ẹ ti jẹ lọkan mi, ãrin ọkan mi ni ẹ wà, ohun ti ẹ ṣe fun mi ko le ṣẽ gbagbe lailai, nko si le san a fun yin rara, ẹniti o ti itori ẹni fi ẹmi rẹ wewu ti pari õre. Bi ko ba si ẹnyin ode ọrun ni akukọ iba kọ ba mi lọjọ oni. Ẹ ku itọju mi, ẹ jọwọ ẹ ba mi fi ọwọ ba onjẹ kekere yi bẽ ki ẹ si mã reti emi pãpã ni agogo mẹrin ọla. Baba ki yin, iya mi si ki yin pẹlu.

Emi ni tiyin,

Ifẹpade.'

"Bi iwe ọmọ nã ti ri ni yi, nigbati mo si ka a tan inu mi dun ju ohun ti mo le fi ẹnu sọ, nigbati mo ṣi onjẹ nã wò mo ri i pe pẹpẹiyẹ ni nwọn pa, pẹpẹiyẹ nã ki isi iṣe ọkanṣoṣo, mẹfa ni.

"Emi nã fesi iwe Ifẹpade, ohun ti mo si kọ ni yi:

"'Ọjọ Kẹwa Oṣu Kejilã, Ẹdẹgbẹwa Ọdun O le Mẹrindilãdọta Lẹhin Iku Oluwa Wa,

Ifẹpade mi ọwọn,

Bi o ti ṣoro fun ọmọ ọjọ mẹta lati sọ itan baba rẹ ni o ṣoro fun mi lati sọ bi inu mi ti dun to nigbati mo ri iwe yin pẹlu onjẹ rẹkẹtẹ ti ẹ ko ranṣẹ si mi. Mo fẹ ki ẹ mọ pe ọran wa yi ki iṣe oju aiye rara, Olodumare ni o ran wa si ara wa. Bi ẹ ba sọ ibiti mo duro le lori ẹmi yin, nko ro pe, sibẹ, o to bi ẹ ti jẹ lori ẹmi mi. Ṣe akiyesi, Ifẹpade, njẹ bi enia ba





mú ẹmi pẹpẹiyẹ kuro lara pẹpẹiyẹ, pẹpẹiyẹ le ṣe nkankan mọ ndan? Tabi ki enia mu ẹmi akukọ kuro lara akukọ kini yio tun kù si i lara? Bakannã ni ẹ jẹ si mi, ẹnyin ni ẹmi mi emi si ni akukọ ati pẹpẹiyẹ. Kikuro ti mo kuro lọhun lẽkan ko ti ọkan mi wa, ki nmá ba di iyọnu fun baba ni. Bi o ba ṣe bi mo ti fẹ ni nkì ba ti kuro lọhun tori yin, ọdọ yin ni nbá wà titi ilẹ iba fi ṣu. Nitorinã ng o mã reti yin lakoko ti ẹ wi lọla.

"'Emi ni tiyin gãn,

"'Ireke-onibudo.'

"Iwe ti mo kọ ni eyi, ọrẹ mi. Ki nsi sọ õtọ fun ọ kọ? Ọmọ nã wu mi pupọ mo si nfẹ fẹ ẹ. Nko sun mọju ọjọ keji ti mo kọwe yi, ẽkan ṣoṣo ti mo pa oju de ọmọ nã ni mo la ala ri.

"Nigbati ilẹ mọ lọjọ keji ti mo wẹ tan ti mo si jẹun mo bẹrẹsi ṣe itọju iyãra ti nwọn fun mi ninu ile ti mo wọ si, mo ṣe e dãdã nitori igbati alejo mi ba mã de ni ìrọ̀lẹ́. Ọjọ keji ti mo ti pa ejo apanirun ni ilu nã ni mo ti lọ si ode ti mo ra ogunlọgọ aṣọ nitori mo ni owo lọwọ ṣugbọn nko ni aṣọ. Nigbati o di agogo mẹta lọjọ ti mo nreti alejo yi, mo ko awọn ẹwu mi kalẹ, mo mu dàńṣíkí àrán kan mo wọ ọ, mo wọ ọ tan mo wo ara mi ninu digi mo ṣe akiyesi pe oju mi ko dan tobẽ mo si mu nkan fifi pa ara mo fi pa ara, nigbati mo ṣe eyi ti mo tun wo digi oju mi dan jù, mo si bẹ ọkan ninu awọn ọmọ ti ngbe ile nã ki o yara ba mi lọ ra àtíkè, o lọ, ṣugbọn ki o to de iṣẹju marun pere ni agogo mẹrin kù mo ba yara bu atike lu oju mi, mo mu aṣọ kekere ti mo fi nnu oju mo fi nù u ṣugbọn ibiti mo ti nnù u ni ọmọ kan wa sọ fun mi pe nwọn nbẽre mi. Igbati mo si bẽre ẹni nã nwọn ni ọmọ ọba ni, mo si yara mo lọ pade rẹ. Eyiti o dùn mi jù ni gbogbo nkan nã ni

pe nko fẹ ki ọmọ ọba nã mọ pe mo kun atike ki o má ba ni ero ninu rẹ̀ pe fãri mi ti pọ ju nitori bi fãri ba pọ ju ṣe ni o ntẹ ni, ṣugbọn bi o ti wọle ṣe ni mo ri i ti o mu aṣọ ninu oju ọwọ rẹ̀ ti o fi gbọn atike ọrun mi, nkò nu u tan nigbati mo nnu oju. Nigbati o si nnu u bayi mo ṣe oju bi ẹnipe nkò bikita biotilẹjẹpe oju nti mi ni isalẹ inu mi.

"Ọmọbinrin nã wa bi ọmọ ọba ni. Ālãrì ni aṣọ ti o ro, ẹnikẹni ko si lo o ri, tuntun gbã ni, lẹhin eyi o we gele àrán kan ti o ba alãri nã mu, o we gèlè nã si ibi iwaju ori o si yọ ọwọ rẹ̀ soke ni apa osi, bùbá àrán pupa kan l'o wọ̀ o si wọ salubata ilẹkẹ, apamọwọ ilẹkẹ nã l'o gbe lọwọ irin ti nwọn si fi yi eti apamọwọ nã ka, gõlu ni, nwọn si tun fi gõlu ṣe ilẹkẹ wẽrẹ pupọ nwọn ge awọn ilẹkẹ nã ni dọgbadọgba nwọn si so o mọ eti apamọwọ lọ, bi o ti nrin ni awọn ilẹkẹ nã nṣe jinwinjinwin. Iborun ọmọ nã jẹ dàmãsi ti o ndan ti o si nfi onirũru àwọ̀ si ode. Ara ọmọ nã pãpã ndan, o mọ tonitoni o dabi ara ọmọ tuntun õjọ, ko si ẹyọ ifọ̀n tabi kuruna kan ṣoṣo lara rẹ̀ bẹ̃ni ko si oju àpá egbo kan, o kun atike fẽrẹ si oju o si fi nkan olõrun didun si ara, gbogbo ẽkan ọwọ rẹ̀ l'o ge ti o si wẹ̀ wọn ti nwọn mọ patapata, atẹlẹwọ rẹ̀ nã si mọ tonitoni, o rọ̀ o si tutu mọ ni lara. Gbogbo nkan ti ọmọ nã fi si ara l'o ba a mu, o ni nkan, o si ni ara ẹ̀yẹ.

"Nigbati o wọle mo gbe aga fun u mo si gbe aga temi nã sunmọ ọ a bẹrẹsi ọrọ isọ. Bi a ti nsọrọ yi mo tun kiyesi nkan miran nipa ohùn ẹnu rẹ̀, ki ikigbe sọrọ rara, a rọra mã sọ ohun ti o ba nsọ ni, ọrọ nã a si mã gbadun mọ ẹniti o ba ngbọ ọ lara. Bi o ti nsọ ọ nã ni yio mã rẹrin musẹ, ehin ẹnu rẹ̀ a si funfun bi ojo dídì.

"Ọrọ ti a sọ ko pọ pupọ nã ṣugbọn mo lù u lẹnu





gbọ ọrọ diẹ nipa ero inu rẹ̀ si mi, mo ni, 'Ọ̀rọ̀ ti baba tilẹ sọ lana si mi, bawo l'o ti ri loju rẹ ?' O dahun o ni, 'Ọrọ wo ?' Emi nã si tun dahun mo ni, 'Nipa eyiti baba sọ pe on o fun mi l'ọmọ.' Nigbati mo wi bayi, ko rẹrin o si fesi o ni, 'Baba nsọ tirẹ̀ ni, ko le fi agbara mu ẹnikẹni fẹ ọkunrin, nigbati ki iba ṣe oluwarẹ̀ l'o mu ọkunrin nã wa si ile pe o wu on.' Emi nã si tun ṣebi ẹniti o kin ọrọ rẹ̀ lẹhin mo ni, 'Ki itilẹ ṣe awọn ọmọ iwoyi ni enia le ṣe bẹ̃ si.'

"A tun jọ ṣire diẹ si i, mo gba apamọwọ rẹ̀ mo yẹ inu rẹ̀ wò mo si ri digi kan ti nwọn fi gõlu ṣe eti rẹ̀, mo yẹ ẹ wo titi o si sọ bi digi nã ti ṣe de inu apo on fun mi, o ni baba on ni o ra a fun on gẹgẹ bi ẹbun nigbati on nṣe ọjọ ibi on.

"Lẹhinnã a ta ayò diẹ nitori ọpọn ayò wà ninu ile nã, ọmọ nã si pa mi ni meji emi pa a ni ọkan.

"Nigbati ilẹ nṣu lọ ti o nto dẽdẽ agogo marun-abọ o ni on nlọ si ile, mo bẹ̀ ẹ ki o maṣe binu pe nko fun on ni nkankan mo si sin i si ọna dãdã, a nwo ogiri ti nwọn mọ yi ãfin po bayi ki nto pada.

"Nko gburo ọmọ nã lọjọ keji ṣugbọn ọba ranṣẹ si mi pe ki nmã mura oye ti on o fi mi jẹ nitoripe o wà lọkan on. Ki a má ba ọrọ lọ bi ilẹ bi ẹni nwọn da ọjọ oye nã mo si ranṣẹ si ọmọ ọba obinrin ọrẹ mi ni ãfin. On nã pãpã tun ranṣẹ pada pe ki nwa si ọhun mo si lọ. Ibẹ ni a ti jọ pa ero nkan gbogbo ti o yẹ lati ṣe, iru aṣọ ti o yẹ ki nwọ̀ lọjọ oye ati awọn ti o yẹ ki nwa onjẹ fun. Ọba pãpã tun pe mi o fi kọkọrọ ile rẹ̀ ti o wà ni igboro le mi lọwọ o ni on fun mi.

"Ọjọ nla ni ọjọ ti mo jẹ oye yi, ọba nawo pupọ fun mi. Gẹgẹ bi aṣa ilu nã ẹniti o ba mã joye ti o ṣe pataki bĩ temi nilati kọ rin gbogbo ilu ka ni owurọ ọjọ oye ki o dọbalẹ fun awọn ẹniti nta onirũru nkan, eyiti o

nta ișu, eyiti o nta ọgẹdẹ, eyiti o nta agbado. Ni kutukutu ni mo ti wọ așọ ti awọn iranșẹ ọba tẹle mi ti mo si dọbalẹ kakiri ilu. Lẹhin nã mo bura pe nko ni șe ibi si ilu tabi si ọba, ati pe bi mo ti jẹ igba keji ọba yi nkò ní tì i ki o huwa ti kò tọ, ng o mã tọ ọ si ọna dãdã ni, ng o si fi ilọsiwaju ilu si ipo kini ninu ohun gbogbo.

"Lẹhin ti mo șe eyi, gẹgẹ bi așa ilu nã mo nilati gun ẹșin kãkiri gbogbo ilu ki gbogbo awọn ti mo ti dọbalẹ fun mã dọbalẹ fun mi ki nwọn mã yẹ mi si.

"Gbogbo eleyi ni mo șe, mo wọ agbádá nla mo bọ si ori ẹșin, mo de fila pataki mo dabi ijoye pataki, awọn ọkunrin ti nwọn jẹ ọmọ agbo-ile ọba ni nwọn si duro bi ẹnikeji mi. Awọn iyawo ọba bẹrẹsi jo, ọmọbinrin ọrẹ mi si gba ilu tirẹ lọtọ, ọmọ nã ba mi șe ariya nã gãn ni, nigbati mo si de ãrin ọja ti o bọ si oju ijo mo fi owo lẹ ẹ niwaju odidi pọnun kan ni mo fi lẹ ẹ ni ẽkanșoșo mo șẹ owo nã ni șile meji meji ati șile kan. Șugbọn ni akoko yi gbogbo awọn ara ilu ni o npè e ni iyawo mi.

"Emi ati ọmọ nã nba ọrọ wa lọ mo si pinnu lati wi fun u pe mo mã fẹ ẹ. Aiya mi nja lati sọ fun u nitori nkò fẹ ki o kọ fun mi ki ọrẹ wa má ba bajẹ. Mo ranșẹ si i lọjọ kan pe ki o wa ki mi, mo ranșẹ bẽ nitori ki nba ri aye sọrọ nã fun u ni, nigbati mo ranșẹ tan mo bẹrẹsi ronu bi ng o ti șe sọrọ nã nigbati o ba de, ọrọ ti ng o sọ kò ye mi, mo si wọ iyãra mi mo bẹrẹsi sọrọ si ofo bi ng o ti șe sọ ọ bi o ba de, mo ni, bayi ni ng o șe bẹrẹ ng o wipe: 'Ifẹpade, jẹki a jọ mã gbe bi baba ati iya ti ngbe ni ãfin,' eleyi ko dara to loju mi, mo ni, bayi ni: 'Ifẹpade, mo ni ọrọ kan lati sọ fun ọ, mo fẹ ki o fẹ mi.' Eleyi ko wu mi to pẹlu, mo ni bayi ni ng o sọ, 'Ifẹpade, mo fẹ ki o jẹki a fi ori ọrọ wa





yi tì si ibikan, mo fẹ ki o șe iyawo mi.' Eleyi dara diẹ loju mi, mo tun ronu diẹ si i mo ni bayi ni: 'Ifẹpade, mo fẹ ba ọ sọrọ pataki kan loni, iru eyiti nko sọ ri, mo fẹ ki o jẹki a pari ifẹ wa yi si ibi pataki kan, ki a pari rẹ si bayi pe ki a jẹ tọkọtaya nijọmiran bi awọn baba ati iya wa.' Eleyi tun gùn jù loju mi, mo ni, bayi ni: 'Ifẹpade, mo fẹ fẹ ọ.'

"Ọrẹ mi, emi ni mo wi fun ọ, ibiti mo ti nronu wọnyi ni Ifẹpade de ba mi. Nigbati o wọle, aiya mi ja, nitori o bi mi bi o ti wọle o ni, 'Kini ẹ pe mi si?' Mo dahun pe ki o joko, nigbati o joko tan mo bẹrẹsi sọrọ bi akólòlò mo ni, 'Mo, mo, mo, mo, fẹ, fẹ, fẹ, fẹran yin, Ifẹpade.' Eleyi nã ni mo si le sọ mọ titi o fi dide ti o wipe bi nko ba ni nkankan ti ng o sọ on nlọ. O șe bẽ, o lọ.

"Nigbati o lọ tan mo wa ronu wipe eyiti o dara ju ni pe ki nsọ gbogbo ohun ti mo fẹ sọ si inu iwe, eyini yio bò mi ni așĩri itiju. Mo ba mura mo kọwe si i, nkan ti mo kọ ni yi:

"'Alupayida.

Ọjọ kọkanlã ọsu kejilã,

Ẹdẹgbẹwa ọdun o le mẹrindilãdọta,

Lẹhin Iku Oluwa wa,

Ifẹpade mi ọwọn,

Mo ro pe o to akoko na wayi ti a le sọrọ nipa ara wa. Ẹ ti mọ bi mo ti jẹ, emi nã si mọ iru ẹniti ẹ jẹ, mo sọrọ kan ninu iwe mi ni ijọsi, mo ni bi ẹmi ti șe jẹ si akukọ ni ẹ jẹ si mi ati pe nko le șe nkan pataki kan laisi yin, nitori eyi, mo fẹ ki ẹ jẹki ọrọ ti baba yin sọ ni ijọsi pe on o fun mi l'ọmọ bọ si i ni ãrin emi ati ẹnyin, eyini ni pe ki ọjọ ayọ nã de laipẹ ti emi ati ẹnyin yio mã gbe pọ bĩ tọkọtaya. Ayọ

nla ni eyi yio jẹ fun mi ti ẹ ba le yẹ ọrọ mi yi wo dãdã ki ẹ si fun mi ni esi ti yio mu inu mi dun loni.

" 'Ṣe alafia ni ẹ wa ?

" 'Emi ni tiyin pẹlu ifẹ,
Ireke-onibudo.'

" Mo fi iwe yi ranṣẹ ni owurọ ọjọ keji, ko si fesi iwe nã titi ilẹ fi nṣu lọ, nitorinã mo lọ si ãfin. Mo de ọhun iya rẹ tun wi fun mi pe o lọ si ode, mo ba duro de e.

" Bi o ti de o rẹrin si mi, ko si ti ijoko nigbati mo bẽre lọwọ rẹ, mo ni, 'Ṣe ẹ ri iwe mi ?' O si rẹrin o ni 'O mà kuku ka ọ lara o.' Mo dahun mo ni, 'Ko ni ka mi lara bawo ? Lẹhin nã kò sọrọ mọ o ni on o fun mi ni esi lọjọ keji.

" Nigbati ilẹ mọ lọjọ keji lõtọ, o kọwe si mi iwe ti o kọ ni eyi :

'Alupayida,
Ọjọ kọkanlã oṣu kejilã,
Ẹdegbẹwa ọdun o le,
Mẹrindilãdọta Lẹhin,
Iku Oluwa wa,'

" 'Ireke-onibudo mi ọwọn,
Mo ti ronu pupọ nipa iwe ti ẹ kọ mo si ro pe ko buru bi ẹ ti wi, ṣugbọn mo fẹ ki ẹ wa ri iya mi lalẹ oni. O nfẹ ri yin o.

Emi ni,
Ifẹpade.'

" Iwe kekere ti o fi da mi lohun ni eyi ṣugbọn o mu ihin rere wa ba mi. Nigbati o di alẹ mo lọ si ọdọ iya rẹ bi o ti sọ. Nigbati mo de ọhun mo dọbalẹ dãdã on nã si ki mi dãdã, lẹhin ti iya rẹ ki mi tan o ni ki nwọn gbe aga kan si inu iyãra on fun mi nwọn si ṣe bẹ, lẹhin eyi, emi ati obinrin nã wọle. Nigbati a wọle tan o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni :





" 'Ireke-onibùdó, ọmọde yi sọ fun mi nipa ọrọ ti o ba a sọ, mo si wadi lẹnu rẹ o ni o dùn mọ on ninu, o dun mọ emi nã, mo si mọ pe yio dun mọ baba rẹ ninu. Ṣe iwọ nã mọ nkan ti ó sọ fun ọ lọjọ ti o fi pa ejo apanirun. Ṣugbọn kini kan ni mo fẹ sọ fun ọ ki ó to di pe ọran nã bẹrẹ, nko fẹ ki o ni obinrin miran pẹlu ọmọ mi o, nitori bi emi pãpã ti wà ninu ile yi mo mọ nkan ti oju mi nri lọwọ awọn orogun, bi kò ba si awọn ọmọ mi ti mo duro tì ni, nbá ti kọ baba wọn silẹ. Nitorinã, fi eleyi si ọkan o, on ni akọbi mi. Bi orogun ba nfi oju rẹrin, oro ejo mbẹ ni õkan aiya wọn, bi iwọ pãpã ba si nfẹ gbadun aiye rẹ dãdã ṣọra lọdọ awọn obinrin ; kilọ fun oju rẹ, bi o ba ti ṣe eyini aiye rẹ yio dara, iwọ ati ọmọde yi yio sì fẹran ara yin. On pãpã jẹ ọmọ rere ni, bi ó ti wà ni ibi yi gbogbo awọn ọmọkunrin l'o nfẹ ẹ, kò gbà fun wọn ni. Iwọ pãpã jẹ enia rere, ẹniti a kò le gbagbe lai ni ọ, nkan ti o ṣe nipa ọmọ yi jẹ nkan ti emi ati baba rẹ ko le gbagbe titi aiye. Nitorina fi ọrọ wọnyi si ọwọ osi ki o má si ṣe fi ọwọ ọhún jẹun.'

" Ọrọ ti iya nã sọ ni yi emi nã si fun u ni esi mo ni :

" 'Ẹ ṣe e pupọ fun gbogbo ọrọ ti ẹ sọ. Ki Olodumare jẹki ẹ pẹ laiye fun wa. Emi pãpã kò fẹ ọran wipe a nko obinrin jọ, mo tilẹ ti ni eyini s'ọkan nigbati mo wà ni kekere, nitorinã ẹ maṣe bẹru eyini rara ọkan mi ko si ninu iru nkan bẹ, obinrin kan igbadun kan ni, obinrin meji, ijangbọn meji, obinrin mẹta ijangbọn mẹta, obinrin bẽrẹ, ijangbọn bẽrẹ ni, bi mo ba ti yanju eleyi ti mo gbe e ni iyawo o tan.

" 'Ṣugbọn kini kan ni mo tun fẹ bẽre lọwọ yin, iya, bawo ni mo ti ṣe mã sọrọ nã fun ọba ? Nko mọ ẹnikẹni ni ilu yi ti mo le ran si wọn.'

" Nigbati mo wi bayi iya nã rẹrin o ni, 'Kini a ti

nṣe enia ? Enia ti o pọ lọ yanturu yi, bi Ifẹpade ba ṣetan yio mu ọ lọ si ọdọ ọrẹ ọba kan, oluwarẹ̀ jẹ ọlọrọ mi mo fẹran rẹ̀ dãdã, on ni ki o ran ki o wa ba ọ tọrọ ọmọ nã ni ãfin.'

"Ibẹ ni a pari eleyini si, nigbati o si pẹ diẹ ti mo ṣetan ti mo nfẹ lọ o pe Ifẹpade ki o wa mu mi lọ si ibiti o wi on nã si tẹle mi.

"Nigbati o pẹ o mu mi yà si ọna ile kan bayi, a wọ inu ile nã lọ, àkòdì ni nwọn kọ ọ, nwọn si so ẹṣin kan mọ iloro. Nigbati a wọ inu àkòdì nã tan o ki awọn obinrin ile gbogbo, nwọn si ti mọ ọ dãdã nwọn nba a ṣe àwàdà. Nigbati o ki awọn obinrin tan o wọ inu iyãra kan bayi o ni ki nduro si ita de on, o pẹ diẹ ninu iyãra nã o pè mi ki nwọle, nigbati mo de ọhun mo ri baba kan ti o dagba diẹ, ko kuku darugbo o, mo dọbalẹ mo si nki i, were o ni ki nmá dọbalẹ fun on, emi ti mo jẹ igba keji ọba, a si jọ ṣe àwàdà diẹ, lẹhin nã o bẹrẹsi sọrọ o ni, 'Mo ti gbọ nkan ti o fẹ sọ, o ye mi dãdã, o ye mi dãdã, ọmọ mi yi, Ifẹpade, ti sọ gbogbo rẹ̀ fun mi. Ng o lọ ri Alaiye lọla, tani inu rẹ̀ kò ni dùn si eleyi ni 'lẹ yi, nkan kekere kọ l'o ṣe fun wa, ti o gbà wa lọwọ ejo apanirun ! Bi mo ti ba ejo nã laiye ni eyini, o si ti npa enia jẹ ni ilẹ yi ọjọ ti pẹ.'

"Lẹhin ti o sọ bayi o bẹrẹsi ki wa lemọlemọ, ẹ ku ijoko, ẹ ku ijoko, ẹ pẹlẹ, ẹ pẹlẹ ete. Nigbati o ṣe o ke si iyawo rẹ̀ kan o sọrọ kẹlẹkẹlẹ kan si i leti onitọhun nã si wọle o mu obi ajõpa mẹfa fun wa, awa nã gba a tan a dide, o ni ki a ba on ki iya Ifẹpade.

"Nigbati a fi mã jade ninu ile nã ilẹ ti nṣu pupọ Ifẹpade si wi fun mi pe ki nmã lọ si ile ṣugbọn nko lọ, mo sin i pada de ãfin mo jiṣẹ fun iya rẹ̀ ki nto mã lọ si ile.

"Nigbati o di owurọ ọjọ keji lõtọ, ọkunrin nã lọ





si ile ọba, nigbati o si to agogo mẹwa o ranṣẹ si mi pe ki nwa mo si lọ. Nigbati mo de ọhun o jiṣẹ fun mi pe ọba ni on fi tayọtayọ fi ọmọ nã fun mi.

"Lẹhin eyi emi nã lọ ri ọba fun ara mi mo si dupẹ lọwọ rẹ̀.

"Lati igba yi lọ ni emi ati ọmọ nã ti bẹrẹsi lo iru ifẹ ti o ṣoro lati ba pade ninu tọkọtaya ni ode oni.

"Ko si ọjọ kan ti a ko ni ri ara wa, bi nko lọ si ọdọ rẹ̀ yio wa si temi. Ṣibi kanṣoṣo ni awa mejeji fi ijẹun, bi o ba bu ẹkun ṣibi ireṣi tabi ẹwa a gbe e fun mi, ng o bu diẹ jẹ eyiti o ba ṣẹkù on nã a jẹ ẹ. Bi mo ba bu okele iyan tabi ọka ng o ge diẹ jẹ lara okele kan ng o fi iyoku fun u, bi on nã ba si bu okele yio ge diẹ jẹ yio fi iyoku fun mi. Bi amodi ba nṣe e bi ikun ba wà ni imu rẹ̀ emi ni mo nba yọ ọ bi o wà ni temi on nã ni o yọ ọ fun mi bi o ba nlọ si ode emi ni mo nwẹ ẹ l'eṣẹ, on nã l'o si nwẹ ẹsẹ temi fun mi. A nfi ọwọ kọ ara wa lọwọ rin ni, nkan kannã ni a njẹ, aṣọ kannã ni a nwọ, orín kannã ni a nrùn ; bi mo ba fi ẹsẹ gbun okuta, on nã a tikararẹ fi ẹsẹ tirẹ̀ gbun u, bi o ba si fi ẹsẹ tirẹ̀ gbun okuta emi nã a fi temi gbun u funra mi. Igba mejilelãdọrin ni a nfi ẹnu ko ara wa lẹnu lojumọ, o jẹ ẹ̃mẹfa ni wakati kan. Ọpọlọpọ itan ti o pa ni lẹrin ni mo ranti nibiti a ti nlo ifẹ wa : lọjọ kan a jọ lọ si ọna oko a si de oju omi kekere kan, omi nã kò jin ṣugbọn o ni àbàtà nwọn si gbe igi tẽrẹ kan le ori rẹ̀, nigbati a de ibẹ mo gbe Ifẹpade mo fẹ gbe e kọja lori igi, bi mo ti fi ẹsẹ tẹ igi ṣe ni ẹsẹ mi yọ, awa mejeji si ṣubu si inu àbàtà, bẹ̃ nã ni a gbe ara wa de ãfin.

"Nigbakan kẹ̀, a gun oke kan de ori a si fẹ mã sọ ọ kalẹ l'odi keji, on wà niwaju, bi o ti gbe ẹsẹ si iwaju ni ilẹ yọ ọ mo ba di i mu ki o mà ba ṣubu ṣugbọn ṣe ni ilẹ tun yọ emi nã, awa mejeji ṣubu a si nyi lọ si isalẹ gbirigbiri, a nyi le ara wa lori ni.

"A lo ifẹ pupọ si ara wa, bi mo ba gun igi a mã gun u wa ba mi. Nigbakan ti o lọ si idalẹ ti o ba baba rẹ lọ, omi nla kan bayi ni o pin ilu Alupayida ni iya si ilu ti nwọn lọ, ṣugbọn ojojumọ ni mo nwẹ omi nã kọja ni kutukutu ti mo nlọ ki i ti mo si tun npada si Alupayida ki ilẹ to ṣu. On nã a sin mi de eti omi a si mã ki mi bi mo ti nwẹ lọ, bi mo ba wẹ omi nã tan a tun mã ke si mi lati oke odo lọhun a o si mã sọrọ titi mo fi mã rin ti nkò ni gbọ ohun rẹ mọ.

"Bayi ni a nlo ọpọlọpọ ifẹ pẹlu ara wa, nigbati o si ṣe a da ọjọ igbeyawo wa. A bẹrẹsi mura fun ọjọ nla yi, baba rẹ ra irinwo malũ, ẹgbẹrin ìgàn aṣọ, ẹgbẹrun garawa epo pupa, odidi ile mẹfa kun fun iṣu, mẹfa kun fun agbado, mẹfa kun fun erẽ, mẹfa kun fun awujẹ, mẹfa kun fun ẹgusi, ọgọrun apo iyọ, ọgọfa apo ata, ogoje apo alubọsa, gbogbo awọn wọnyi wà ni ilẹ, gbogbo ọba igberiko ni ọba si ti pe si igbeyawo yi.

"Ṣugbọn, ọrẹ mi, ero ni ti enia, ti Olodumare ni iṣe, gbogbo bi imura ti pọ to fun igbeyawo yi, igbeyawo nã ko bọ si i, awọn araiye bọ si ãrin wa, bayi ni: Nigbati mo ba ti lọ si ãfin tẹlẹ ti ilẹ ba ṣu pupọ iya ọmọ nã a ni ki nkuku sun si ãfin ile ti nwọn si mã nfun mi ki nsun jẹ eti ibiti awọn ayaba ti mã nsun, bẽ pupọ ninu wọn ni o nrin ihõho nigbati nwọn ba nwa onjẹ ọba. Ọba kò mọ pe ino mã nsun ni ile nã rara. Nigbati o ṣe, awọn olofofo lọ sọ fun u pe ọdọ awọn iyawo rẹ ni mo nsun. Lalẹ ọjọ kan, mo wà ninu ile nã pẹlu Ifẹpade, mo dede gbọ ohun ọba, a rọra dakẹ a kò sọrọ mọ, ṣugbọn sibẹ ọba tubọ nsunmọ ibiti mo wà apo ekurọ kan ti nwọn tò sibẹ ni mo bọ si mo wi fun Ifẹpade ki o bọ si ita. Ọba wọ ibiti mo wà ninu apo ekurọ nigbati Ifẹpade jade tan, o si bẹrẹsi wa ibẹ kiri, nigbati o ṣe o fi ọwọ kan mi lori ninu apo, o si





wo inu rẹ o ri mi, o fà mi jade tagbaratagbara, o si wi fun awọn iranṣẹ rẹ pe ki nwọn mã lu mi awọn nã si nlu mi pẹlu agbara nwọn fi ẹhin mi na ilẹ nwọn fẹrẹ lu mi pa. Lẹhin ti nwọn lù mi tan ni ọba nã tun wi fun mi pe ọjọ meje lẹhin ti on mu mi pẹlu awọn iyawo on ni on mã mu mi kuro lori oye ti on si mã da mi dọbalẹ ni ãrin ilu ti on mã nà mi.

"Inu iyawo mi bajẹ pupọ si ọran yi, ẹkun ni o fi gbogbo oru sun, oru nã ni mo si wa si ile mi. Lọjọ keji mo ṣebi ng o ri Ifẹpade ṣugbọn nko ri i, àṣé o yi ode lọ si ọdọ awọn agba ilu lati lọ fi ẹjọ baba rẹ sùn ni ati lati wi fun wọn ki nwọn wi fun u pe ki ó má ṣe ohun ti o tun ni on fẹ ṣe si mi. Mo ranṣẹ si i ni ọjọ kẹta pe ki o wa ṣugbọn awọn orogun iya rẹ ti nwọn wà ni idi gbogbo rikiṣi nã ko jẹki ẹniti mo ran ri i. Ni ọjọ kẹrin baba rẹ pãpà wi fun u pe on ko gbọdọ ri i ki o jade si ita o si kọwe si mi ṣugbọn ẹniti o fi iwe ran ko fi jiṣẹ, eleyini nã wà ni idi ọtẹ nã.

"Ki ilẹ ọjọ keje to mọ mo ti di ẹru mi mo sa kuro ni ilu Alupayida ṣugbọn nkò sọ fun Ifẹpade rara, èpè ni mo tilẹ nṣẹ fun u nigbati mo nlọ. Mo kọwe buruku kan si i ṣugbọn ko ri i gba. Mo tun kọ ikeji ti o buru ju ti iṣãju lọ. Nkan ti mọ kọ si inu iwe mi keji ni yi:

'Ọjọ Kọkanlelọgbọn,
Ọṣu Kejilã, Ẹdẹgbẹwa ọdun o,
Le Mẹrindiladọta Lẹhin Iku Oluwa wa.

Ifẹpade mi ti ko ṣọwọn,

Mo ro pe o to akoko ki nwa sọrọ fun ọ, Ifẹpade, o to akoko, o to gẽ, o wà gẹgẹ bi alainitiju enia, Olodumare si wà lãrin temitirẹ. Kini ẹnyin obinrin mọ nipa ọkunrin ju pe ki ẹ duro bi apata lẹhin rẹ nigba igbadun, ki ẹ sa bi igbati ọmọ ẹran ba sa fun kiniun nigba wahala, ki ẹ ko dukia rẹ fun ilo ara

yin, ki ẹ mã lo ọla ki ẹ si ma yọ ninu aṣọ olowo iyebiye, ki ẹ mã pe pẹlu awọn enia pataki, ṣugbọn ẹ dabi ejo oloro labẹ koriko, paramọlẹ ti nbu enia l'ẹsẹ jẹ, ẹniti nda ija silẹ ti o nta kete, bayi ni ẹ jẹ, ẹnyin obinrin. Ṣugbọn, iwọ, Ifẹpade, kini alakọri rẹ gbẹkẹle ? Ṣe baba rẹ yi nã ni, kini ati iwọ ati baba rẹ jamọ ? Kini enia nfẹ lara iwọ pãpã ?—Iwọ jágbajàgba, réderède, rándanràndan, gálagàla, jágajàga, yágbayàgba, o wà o ko ni ero lori rara, ko si ibiti o kò lè de, bọya o tun ti ba ọkunrin miran lọ ni, ki iwọ ati baba rẹ mã ṣe bi ẹ ba ti fẹ, bi iwọ pãpã tilẹ tun fẹ fẹ mi nko fẹ ọ mọ, mo lọ fun ọ ati fun oloriburuku baba rẹ nã o.

Emi ni, Ireke-onibudo.'

" Ọrẹ mi, eyiti o yà mi lẹnu julọ patapata ni pe ọjọ ti mo kọwe yi gãn ni on nã kọ ọkan si mi, kò mọ pe mo nlọ lọjọ nã, nko ri eyiti on kọ, on nã ko si ri temi, ṣugbọn nigbati a pade, ọjọ eyini pẹ, ng o sọ ọ niwaju, igbati a pade ni a wa ri gbogbo iwe ti a ti kọ si ara wa ni ọjọ ipinya yi. Iwe ti on kọ si mi yatọ si temi lọnakọna bayi ni iwe nã lọ :

' Ọjọ Kọkanlelọgbọn Oṣu Kejilã,
Ẹdẹgbẹwa ọdun o le
Mẹrindilãdọta lẹhin iku
Oluwa wa.

Ireke-onibudo temi pãpã,

Ireke-onibudo mi, orukọ rẹ ba ireke lọ ṣugbọn iwọ pãpã dun ju ireke lọ. Iwọ ni igbin emi ni ikarawun, igbin ko le ṣe airi ikarawun, ikarawun ko si le ṣe airi igbin, ati ọjọ ti ọran yi ti ṣẹlẹ ti nko ri ọ, bi aiye ni mo wà bi ọrun ni nko le sọ, ati ijẹta ni mo ti fi onjẹ si ẹnu mi yi mọ . Bawo ni ng o ṣe jẹun nigbati olufẹ mi ko jẹ, bawo ni ng o si ṣe mu omi,





nigbati olufẹ mi ko mu ? Ọkan mi ti dàrú bi omi elẽri, aiya mi kò balẹ, ibanujẹ ni mo si fi ṣe aṣọ nitori rẹ. Tani le dipo olufẹ mi fun mi ? Tani le ṣe bi olufẹ mi ? Ireke-onibudo ti ta ọfa ifẹ lù mi lati ọjọ pipẹ oró ọfa rẹ si ti mu mi, olufẹ mi dabi itanna eweko tutu olõrundidun ti nfa gbogbo enia mọra. Ireke-onibudo, maṣe gbagbe, ifẹ dabi onjẹ didun ni oko ṣugbọn ọna ati de oko nã a mã kun fun iṣoro, iṣoro oke, iṣoro kòtò, iṣoro ẹ̀gún, iṣoro onirũru igi giga ti o mã nwo lu oju ọna nã, ṣugbọn ẹniti o ba le bori iwọnyi ti o de oko yio ni alafia aiye yio ni ti ọrun pẹlu. Nitorinã jẹki a daraya, iwọ olufẹ mi, mo nbọ wa ri ọ lalẹ oni.

Emi ni tirẹ titi aiye,
Ifẹpade.'

" Nigbati o fi iwe yi ranṣẹ si ile mi ti nwọn wi fun u pe mo ti lọ ni ilu, ko ṣe nkan meji, o di ẹru rẹ ko si sọ fun ẹnikẹni, on nã fi ilu silẹ. Owo diẹ l'o mu lọwọ ko si mọ ibiti mo ba lọ, o fi ori le ọna ibiti o ro pe mo ba lọ ni, o si ṣe ibura lẹnu bode ilu wipe on kò ni pada wọ ilu nã afi bi mo ba pada pẹlu on.

" Ọna ibiti ó ba lọ kọju si ila õrun temi kọju si iwọ rẹ bi a si ti nrin siwaju ni a tubọ njina si ara wa.

" Nigbati o rin irin ọjọ meje ti ko ri mi o de ilu kan o si duro nibẹ nitori ko si owo lọwọ rẹ mọ, o bẹrẹsi ṣe iṣẹ, o nṣẹ igi ta o si nta ewe. Bi o ti nta nkan wọnyi ni o ndarukọ mi tọsantoru bi emi nã si ti nlọ ni mo ndarukọ rẹ ti mo npe e lorukọ buruku gbogbo ti mo si nṣẹ epe fun u.

" O kuro ni ilu ti o kọ de yi, nibiti o si ti nrin lọ ilẹ ṣu on nikan si inu igbo awọn kiniun si nke niwa lẹhin.

" Ninu irinajo rẹ o ba ogunlọgọ enia nla pade ti




" On nã fi ilu silẹ."





nwọn nbẹ̀ ẹ ki o fẹ awọn ti kò si fẹ wọn, a ni ki nwọn ba on wa Ireke-onibudo on. Igbanã emi nã nrin kiri mà si dede mã darukọ rẹ soke wipe, ' Ifẹpade oloṣi, Ifẹpade ọmọ aja, ọmọ ẹran, ọmọ wahala, enia lasan, alainilãri, oloriburuku ọmọ.'

" Emi pãpã nkãkiri ni, o pẹ diẹ ki nto duro ni ilu kan, oṣu mẹta ni.

" Nibiti Ifẹpade ti nkiri o bẹrẹsi kọ onirũru nkan nipa mi si inu iwe pẹlẹbẹ pẹlẹbẹ gbogbo o npin i fun awọn ọmọde ni ilu ti o ba de. Ninu iwe kan ohun ti o kọ ni eyi : ' Ireke-onibudo ẹni igbadun,

' Ireke-onibudo arẹwa ọkunrin
' Ireke-onibudo gbajumọ pataki
' Ireke-onibudo ọlọla enia,
' Ireke-onibudo ẹniti o tutu bi ọgẹdẹ eti odò
' Ireke-onibudo ẹniti o lagbara bi kiniun
' Ireke-onibudo ẹniti o gbọn bi ejo
' Ireke-onibudo ẹniti o ni iwa tutu bi adaba
' A ! Ireke-onibudo, iwọ olufẹ mi, ọjọ wo ni ng o ri ọ ?
' Ẹ ba mi wa a, ẹ ba mi wa Ireke-onibudo mi
' Ẹ ba mi kẹ ẹ, ẹ ba mi kẹ Ireke-onibudo mi
' Ẹ ba mi gẹ̀ ẹ, ẹ ba mi gẹ Ireke-onibudo mi.'

" Nigbati o di ọjọ kan bayi mo ba ọkan ninu awọn ara ilu Alupayida pade ni ọja ni ilu kan, o wi fun mi pe Ifẹpade ti kuro ni ile ati pe o ti wa mi lọ. Ọkunrin nã jẹ ẹniti ile rẹ̀ sunmọ ile mi ni Alupayida o si wi fun mi pe akoko ti mo ti kuro ni ile ni ọmọ nã ti lọ bẹ̃ni oṣu kẹfa ti mo kuro nibẹ ni mo ri i yi.

" Ẹru ba mi nigbati mo gbọ ọrọ yi ẹniti o wi fun mi si wipe ko si ẹnikan ni ilu ti o le sọ ibiti Ifẹpade gba lọ.

" Emi nã tun fi ori le ọna mo nwa a kiri lati ilu de ilu.

" Lọjọ kan, bi mo ti de ilu kan mo ri ọmọde kan ti o

mu iwe kan lọwọ. Nigbati o ṣe o sọ iwe nã silẹ mo si mu u mo yẹ ẹ wo, afi igbati mo dede ba orukọ mi ti ẹni nã kọ sibẹ bayi:

' Bẹni Ireke-onibudo wà lode aiye yi!
Ẹniti iwa rẹ tutu bi omi àmù
Ẹniti o dara bi egbin
Ẹniti o fi gbogbo agbari ṣe ọgbọn
Oloyelori ọkunrin
Ẹni igbadun
Ẹni ọla
Ẹni aiye yẹ
Ẹni ọkan rẹ balẹ
Ẹni Ọlọrun duro tì
Awọn enia nṣe ṣa ni
Nwọn ko le ka apa Ireke-onibudo mi.'

" Nigbati mo ka eleyi wò, mo yara sare tẹle ọmọ ti o sọ iwe nã silẹ; mo ba a mo si bi i ibiti o ti ri iwe nã, o wi fun mi pe obinrin kan ti o nti oko ẹmu bọ ni o mu iwe nã fun on. Niwọnigbati nko si ti ni ero wipe Ifẹpade le mã lọ si oko ẹmu nko le ro pe on ni ṣugbọn mo mọ pe on l'o kọ iwe nã nitori mo mọ ọwọ rẹ ọkan mi si sọ fun mi pe ati pade rẹ kò jina mọ.

" Bi mo tun ti rin diẹ lẹhin eyi mo tun ri ọmọde miran ti o ni iwe yi lọwọ, mo si pe e mo bi i bi o ti ṣe ri i o tun da mi lohun, o na ika si apa isalẹ kan o ni, ' Obinrin ti nta ẹmu lọhun nì ni o npin i fun ni.'

" Nigbati mo gbọ bayi mo mura o di ibẹ, nigbati mo de ita ibẹ mo bẽre nwọn ni obinrin nã wà ninu ile. Nigbati mo si mã wo ita ibẹ orukọ mi ni nwọn kọ si ẹgbẹ ogiri lọ. Mo ni ki nwọn ba mi pe obinrin nã, nigbati o de, o di Ifẹpade.

" Ọrẹ mi, nkan kan ti o ṣoro ninu aiye ni pe ki a mọ bi inu ọmọnikeji ẹni ti ri yala o nyọ ni tabi o nbanu-





jẹ, nitorinã o ṣoro ki o to le mọ bi inu awa mejeji ti dun to nigbati a ri ara wa. Awa pãpã kò le sọ, a di mọ ara wa ni, a si nwo ara wa loju. O sọ fun mi bi iya gbogbo ti jẹ on to ti on si ti bura wipe bi on ko ba ri mi on ko ni pada ati bi oju ti ṣe npọn on tobẹ ti on nilati mã lọ si oko ẹmu.

" Gbogbo iwọnyi ni ọmọ nã sọ, ibiti o ti nsọ ọ, ọkan mi nbajẹ mo si wi fun u ki o má sọ ọ mọ. Mo wi fun u pe ti owo kò jẹ nkankan fun wa mọ nitori emi ni owo lọwọ, mo si wi fun u ki o jẹki a lọ si igboro lẹsẹkannã ki a lọ ra aṣọ ti yio mã lo nitori gbogbo awọn aṣọ rẹ ti di akisa mọ ọ lara. A lọ a ṣi ra onirũru aṣọ gbogbo, ọjọ nã ni a si pinnu ati gbeyawo ni ilu ti mo ba a nã, a si ṣire titi ilẹ fi ṣu, ṣugbọn emi sun si ile ibiti mo de si on si sun si ile ti mo ba a.

" Bi mo ti ji lowurọ ọjọ keji ile rẹ ni mo lọ. Iyalẹnu ni o jẹ fun mi nigbati mo mã wọle rẹ ti mo ba ọlọpa baba rẹ ti mo ti mọ ni Alupayida. Nigbati mo si ti wọle ni Ifẹpade ti pe mi si iyãra ti o fi iwe ti baba rẹ kọ si i han mi. Awọn ọlọpa nã wi fun wa pe oṣu kẹta ti awọn ti nwa wa kiri ni awọn to wa ri wa, ninu iwe ti ọba kọ o ni ki emi ati Ifẹpade mã bọ ki a wa ṣe igbeyawo ati pe on ko binu si mi mọ.

" Nigbati a ronu titi a pinnu pe a ko ni lọ, ṣugbọn awọn ọlọpa nã bẹrẹsi bẹ wa pe ki a jọwọ lọ nitori awọn nitori ọba ti ṣe ileri pe bi awọn ko ba mu ni bọ pipa ni on o pa awọn. Emi nã ni mo si tun ro o wo ti mo wi fun Ifẹpade wipe ki o jẹki a mã lọ.

" Ọna oju omi ni a gba ọjọ meje ni ọkọ wa si gba ki a to tun pada de ilu Alupayida.

" Nigbati a ti nbọ ni a ti ranṣẹ si iwaju nigbati a si mã gunlẹ a ba ọpọlọpọ enia leti okun ti nwọn wa

pade wa. Ọba ran pupọ ninu awọn iyawo rẹ wa, ayọ nla si ni fun iya Ifẹpade lọjọ nã ti o ri ọmọ rẹ.

"A lọ si ãfin lati lọ ki ọba, lẹhinnã emi lọ si ile ti mo ngbe tẹlẹ ki nto lọ Ifẹpade si joko ti iya rẹ ni ãfin. Ṣugbọn ile ti mo ti ngbe tẹlẹ ri, ile ti ọba fi fun mi ni, igbati mo si tun fi mã wọ inu rẹ nwọn ti ṣe e lọṣọ jingbinni, nwọn tẹ ẹni ati aṣọ ti o nipọn yi ilẹ ibẹ po, iyẹ l'o wà ninu timutimu ti nwọn gbe le ori ibusun mi, bakannã si ni ti ori aga pẹlu. Gbogbo awọn awo ati ife ti nwọn kó si inu ile nã, ti fadaka ni, nwọn si mu òdòdó nwọn ja a nwọn fi ṣe ọṣọ yi ile po, ilẹkun gbogbo ndan bĩ digi, gbogbo ibẹ si nkọ mọna, ile nã gbadun pupọ.

"Ibẹ ni mo sun mọju ọjọ keji, bi ilẹ si ti nmọ lọjọ keji ni mo lọ wo Ifẹpade ni ãfin.

"Nigbati mo yọ si i ṣe ni gbogbo oju rẹ npupa nibiti o ti nsọkun, aiya mi ja lati ri omije loju rẹ mo si ki i, ṣugbọn imu l'o fi da mi lohun, nwọn ti kó gbogbo awọn iwe buruku ti mo kọ si i nigbati inu fi nbi mi fun u, o dahun o ni, 'Mo ti ri awọn iwe rẹ.' Nigbati o wi bayi ọkan mi rẹwẹsi mo si mu u wọ iyãra rẹ lọ, mo bẹ ẹ mo dọbalẹ fun u gãn ni, mo bẹ ẹ pupọ pe ki o dariji mi ati wipe aimọ ibiti o wà nigbanã l'o jẹki nṣe bẽ, mo fi aṣọ nù u loju o si rẹrin a si tun jọ nṣire.

"Ṣugbọn nigbati o pẹ diẹ o wi fun mi pe ori nfọ on otutu si npa on. Were mo yara da ina mo si wa nkan diẹ mo fi pa a ni iwaju on nã si fi ẹhin le ilẹ o sunlọ.

"Mo pada wa si ile mi mo wa jẹun.

"Nigbati o di ìrọ̀lẹ́ mo tun lọ si ãfin nigbati mo si de ọhun mo ba a nibiti o gbe nṣire ara rẹ ti ya.

"Ṣugbọn nigbati o di owurọ ọjọ keji, bi ilẹ ti nmọ hai ni nwọn wa kan ilẹkun ni ile mi, nigbati mo si mã yọju wo oluwarẹ o di ẹnikan lati ãfin ti Ifẹpade





ran si mi pe on kò sun mọju, mo ba tun yara lọ a si wa nkan si ara rẹ ti kò le, ati igba yi ṣa ni ara rẹ ti nle diẹdiẹ o si to ọsẹ kan ki o to le dide.

"Ko pẹ pupọ nã ti ara rẹ fi nya ti awọn ara ile rẹ fi wi fun mi ki nwa ṣe igbeyawo, ki nmu iyawo mi. Ọkan mi ko fẹ ṣe bẽ nigbanã nitori o rù diẹ nko si fẹ ki wahala igbeyawo tun lọ dapọ mọ ọ ṣugbọn nigbati ọba pãpã pe mi ti o tẹnumọ ọrọ nã, mo gbà, a si gbeyawo.

"Ọrẹ mi, ọjọ kẹfa ti ọmọ nã wọle mi l'o tun bẹrẹ aisan, aisan nã pọ tobẽ gẽ, nigbati o si di oṣu keji ti mo ti nwo o, o pe mi lọjọ kan o wi pẹlu omije bayi o ni: 'Bãle mi, mo mọ daju pe ori aisan yi ni ng o ku le, o dun mi pe bayi ni ifẹ wa mã pari si, o mà ṣe o.'

"Ẹru bà mi nigbati o wi bayi, omi bọ loju mi, mo wi fun u ki o má sọrọ buruku, pe ko si nkan.

"Nigbati o di ọjọ keji, lọsangangan, Ifẹpade ku.

"Ara mi gbona lati oke de ilẹ ko, mo sọkun kikoro, mo ronu titi, nko mọ eyiti mo le ṣe, nigbati nwọn tẹ ẹ silẹ mo sùn ti i mo fi aṣọ rẹ bora nitori ero mi nigbanã ni pe ki nri nkankan ki o mu ẹmi mi kuro. Aiye su mi gbã, o dabi ẹnipe nko ni nkankan ninu aiye mọ ni.

"Nigbati nwọn tu ọfọ nã fun ọba on ati iya Ifẹpade subululẹ nwọn daku nigbakannã ni, o si pẹ ki nwọn to ji, ọba fẹran ọmọ nã pupọ. On ni arẹmọbinrin rẹ o si jẹ ẹniti o ni ãṣiki, gbogbo enia l'o mọ ọ ni ilu dãdã.

"Nigbati nwọn mã ṣe isinku, gbogbo awọn ara ilu l'o wọ aṣọ dudu ti nwọn tẹle posi idẹ ti nwọn gbe oku rẹ si. Bi nwọn ti ṣe eto nã ni yi: ãfin ni nwọn ni lati sin oku rẹ si, gbogbo awọn ara ilu nilati pe jọ ki nwọn to ara wọn lẹsẹsẹ ki nwọn tẹle posi ti yio gbe oku lati ile mi lọ si ãfin, bi nwọn si ti ṣe eto ni yi—awọn ọmọ wẽrẹ tò lẹsẹsẹ siwaju posi, awọn ọrẹ Ifẹpade obinrin tẹle posi nã, awọn ọrẹ ati ẹbi iya rẹ tun tẹle wọn,

lẹhinnã l'o kan awọn ara ile ọba ni ãfin, emi ati awọn ijoye gbogbo ni o kẹhin wọn, ẹkun ni mo si nsun ni temi.

"Nigbati nwọn de ãfin ti nwọn tẹ ẹ silẹ mo kigbe nla, ori mi wú nigbati mo ranti bi o ti mã nṣe, mo wo o mo si bẹrẹsi ọrọ isọ mo ni:

"'Ifẹpade, olufẹ mi, olufẹ mi, olufẹ mi ọwọn julọ, bayi ni oṣupa rẹ wọ okunkun lọsangangan! Igbesi aiye ọmọ enia kun fun lãlã on ẹkun, ibanujẹ on wahala, ati ogunlọgọ irora, Ifẹpade, o ṣe bẽ o lọ; o sọ mi di ẹni ironu lode aiye, mo di elẽri patapata, nitori iwọ Ifẹpade ni wura ati fadaka mi, wura bajẹ loni fadaka sọnu, ifẹ ailabawọn bọ sọnu lọwọ mi, oniwatutu fi aiye silẹ ni gbigbona fun mi. Aiye yi emi ati olufẹ mi si ibi ibajẹ, ifẹ ja lagbedemeji bi fọnran owu, ṣugbọn kini enia? Ẹmi ni enia—ẹran, egungun ati iṣan ti o papọ lara enia ko jamọ nkankan bi ẹmi ba ti lọ. Ifẹpade ko le gbe ọwọ, Ifẹpade ko lẹ gbe ẹsẹ, Ifẹpade ko si le sọrọ si ni mọ, Ifẹpade lọ. Iku mu gbajumọ lọ, ẹniti ko ṣẽ dipo kuro lori ilẹ. Ṣugbọn kini ero rẹ iwọ Iku? Alailãnu ẹda ni iwọ iṣe, iku ni ọta gbogbo enia ti mbẹ ni ori ilẹ aiye, ọta enia, ọta ẹranko, ọta igi inu igbo, ọta ẹja inu okun, ọta ẹiyẹ oju ọrun. Iku ba mi ṣe ọta loni, o gba Ifẹpade lọ, A! Ifẹpade mi, Ifẹpade mi, Ifẹpade mi ọwọn julọ, aiye su mi nitori rẹ, ọrun nwu mi lọ.'

"Bayi ṣa ni ọmọ nã ṣe ti o ku ti mo gbe ibanujẹ wọ bi ẹwu ni ilu Alupayida.

"Nigbati ọmọ nã ti ku tan ni ilu nã ti su mi ṣugbọn bi ọran gbogbo tun ti ri ko jẹki nle lọ. Ọba pãpã ko fẹ ki nfi ilu nã silẹ, o nfa mi mọra, nigbẹhin o si ran mi ni iṣẹ pataki kan, ng o mã sọ eyini niwaju.

"Ṣugbọn ọran nã ko kuro lara iya Ifẹpade fun ọjọ pipẹ, igbakigba ti o ba ti ri mi ẹkun l'o mã nsun.





"Nkankan si kọ wa yà mi lẹnu ti mo nilati sọ fun ọ, on nã si ni eyi: nigbati Ifẹpade wà laiye ọkan ninu awọn orogun iya rẹ kò fẹ ki nfẹ ẹ ko si fẹran mi, igbati mo ba lọ si ãfin nigbanã bi mo ba ki i, ki ida mi lohun dãdã bẽni ọmọ obinrin nã si jẹ ọrẹ Ifẹpade, nwọn fẹran ara wọn, nwọn jọ mã nrin kakiri ni. Ṣugbọn nigbati Ifẹpade ku tan ni obinrin yi dede bẹrẹsi ba mi mu ọrẹ ti o nwa ile mi. Ni ọjọ kẹta ti Ifẹpade ku ni o gbe onjẹ wa si ile mi, o gbe ẹ ran ọmọ rẹ obinrin ti o jẹ ọrẹ iyawo mi, orukọ ọmọ nã ni Ifẹpinya.

"Nigbati o to bi ọjọ mẹta lẹhin eyi on pãpã tun wa ṣugbọn nigbati o wa yi ọrọ ti o sọ ya mi lẹnu o ni, 'Ṣe ni ki o ṣe oju giri, enia ko kuku tan laiye, awọn ọmọ ọba ṣi pọ ni ilẹ, bi o ba tun nfẹ fẹ ọmọ ọba ko si bi a ti nṣe e.'

"Ifẹpade ku ko pe oṣu kan ti o fi nsọ bayi, o si jẹ ohun iyalẹnu fun mi pe ẹnikan le sọrọ iyawo fifẹ fun mi nigbanã, mo wo o nko fun u l'esi kan.

"Nigbati o wa ṣe o bẹrẹsi ran ọmọ rẹ si mi lemọlemọ, igbamiran ki nto kuro lori ibusun mi lowurọ ọmọ nã a ti de a si wa mã fun mi ni oriṣiriṣi ẹbun, ẹbun nã pọ tobẹ̃ ti mo bẹrẹsi fura pe ọmọ nã nwa oju mi mọra ki nba fẹ on ni ati wipe iya rẹ nã nfẹ ki nfẹ ẹ. Ṣugbọn nigbayi nko tilẹ fẹ ki ẹnikẹni sọrọ aya loju mi ni, iwa buruku patapata gbã l'o si jẹ loju mi wipe ki iru ọmọ bi Ifẹpade ku ki o si di pe orogun iya rẹ kò ni ero meji ju pe ki nfẹ ọmọ on lọ.

"Lẹhinnã mo tun ṣe akiyesi pe igbati iya ọmọ nã ba ti wa ọrọ iya Ifẹpade l'o mã nsọ, lọjọ kan bi o ti de ti o joko diẹ ọrọ ti o ti ẹnu rẹ jade ni pe 'Njẹ ara ile rẹ ti wa ki ọ lati igbati ọfọ ti ṣẹ?' Mo si bẽre mo ni, 'Tani?' O ni, 'Tani iba ṣe, ana yin obinrin kọ?'

Nko si fesi ọrọ nã mọ, mo dakẹ ṣugbọn o mọ pe ko dun mọ mi ninu.

"Ọrọ ti o si tun mã sọ tẹle eyi ni, 'Ireke-onibudo, o ki ijade rara ni ? Lati ọjọ ti Ifẹpade ti ku o ko tilẹ de ãfin, ṣebi awọn ọmọbinrin kù si ãfin, iru Ifẹpinya ti o nwa ọ wa lojojumọ yi o ko tilẹ le sọ pe o mã de ile rẹ ki i, a mọ pe iwọ ati ana rẹ obinrin kọ fẹran ara yin na, ṣugbọn kini ti awa, ṣe awa nwa ọ ?'

"Nigbati o sọ bayi emi nã wa da a lohun mo ni, 'Nko le gbagbe ile iya Ifẹpade bi mo tilẹ gbagbe gbogbo enia, nitori nigbati ọmọ rẹ wà laiye, o tọju mi de ibiti enia ntọju àna mọ, o fi iṣu kẹ mi, o fi iyan kẹ mi, o fi ẹkọ ati ẹran kẹ mi pẹlu, enia ni iya Ifẹpade, mo nbọ wa ki i ṣugbọn ifẹ Ifẹpade ti bo gbogbo ọkan mi mọlẹ bi awọsanmọ ti bo ilẹ ko si jẹki nronu ati de ãfin ki nki àna mi, bi ẹ ba de ọhun ki ẹ ba mi ki i. Iya Ifẹpade ki iṣe ẹni kekere, ẹ maṣe fi i ṣire o, ẹ maṣe fi i ṣire rara.'

"Iwọ ọrẹ mi, inu awọn orogun dudu jù ẽdu, o ṣokunkun bi ọganjọ oru, ìgẹ̀dẹ̀gẹ́dẹ̀ ni mbẹ ni inu wọn, nkankan ṣẹlẹ ni ãfin ni kete ti obinrin yi nwa si ile mi. Obinrin nã nsun ni iyãra ti o sunmọ ti iya Ifẹpade o si jẹ ẹniti o fẹran egbõgi pupọ, ọpọlọpọ igba l'o jẹ pe bi enia ba pẹ lode lalẹ oluwarẹ a ba a ni orita mẹta, igbamiran ni ihõho ni, emi ati Ifẹpade ba a bẹ̃ ri. O wa lọ ṣe õgun kan ti nwọn rọ si inu igo, ẹniti õgun nã ba si kan lara a di adẹtẹ ni. O gbe õgun yi wa si ile lọjọ ti o ṣe e ni ireti ati lọ bu u si iya Ifẹpade lara nigbati onitọhun ba sun. O gbe õgun yi si pẹpẹ loke aja, o fi ẹhin le ilẹ ko si mọ pe on le sunlọ. Bi o ti fi ẹhin le ilẹ tan o sunlọ ; nigbati o di oru ologbo ti o nsa kiri oke aja kọlu igo õgun nã o yi i lulẹ gbogbo õgun inu rẹ̀ si da le e lori, nigbati ilẹ fi mã mọ obinrin





nã di adẹtẹ ika ọwọ rẹ̀ si ti bẹrẹsi ge. Bayi ni o ba aiye ara rẹ̀ jẹ, ẹniti o ṣe õgun nã fun u l'o si tun wa sọ fun mi.

"Nigbati obinrin yi di adẹtẹ ọba ni o nilati jade, nwọn kọ ile rẹ̀ si inu igbo, ko gbọdọ ba awọn enia pe pọ mọ, aiye rẹ̀ ti kuro ni aiye igbadun o di aiye kikoro bi ewuro. Ṣugbọn ọmọ rẹ̀ Ifẹpinya ko ye wa si ọdọ mi, mo nfi oju le e kò tete gbọ, igbamiran bi o ba ti wọle ng o jade ng o wipe mo ni ibikan ti mo fẹ lọ, bi o ba ki mi nko ni da a lohun dãdã, bi o bi mi ni nkan mo le ṣai dahun rara, bi mo ba tilẹ ti ri i inu nbi mi ni nitoripe on ati Ifẹpade ṣe ọrẹ pupọ ki o to ku ko si ti ipẹ ti o ku ti o fi nwa oju mi mọra. Bẹ̃ ni ọmọ araiye ri, ba inu sọ má ba enia sọ, awọn eleke pọ ni inu aiye, ẹniti o ba nṣe bi ọrẹ enia nigbamiran ki ifẹ ni de inu, inu rẹ̀ a mã dun si iṣubu ẹni, ibanujẹ a si de ba ọkan rẹ̀ ni igba ilọsiwaju ẹni, Olodumare ni ọrẹ ti enia le gbẹkẹle patapata, iba diẹ ni enia le gbẹkẹle lãrin awọn ọmọ enia, nitori oju ni aiye mọ̀, eyiti nwọn ba sọ loju kọ ni nwọn nsọ lẹhin ẹni, eyiti o ba tilẹ tun jade lẹnu a mã yatọ si ti isalẹ ikùn. Enia lasan ni Ifẹpinya.

"Nigbati mo bẹrẹsi fi oju le ọmọde nã ko wa si ọdọ mi ju bẹ̃ lọ mọ, nigbẹhin, o di ọta mi gidigbi, nitori bi obinrin ba nwa oju ọkunrin ti ọkunrin ko ba ka a si, ikorira rẹ̀ a dabi igbẹ, a mã sọrọ oluwarẹ ni aidara kiri, a mã pẹgan rẹ̀ de ibiti o ba le pẹgan de, inu rẹ̀ a dudu si ẹni nã bi òkúṣú aro, a kun fun oro bi ejo, a si mã gba onirũru ọna lati wa ibajẹ ẹni.

"Nigbati o di ọjọ kan ti mo fẹ jẹun, bi ọmọ ọdọ mi ti gbe onjẹ kalẹ ti mo fẹ bu okele ni alangba kan jade ninu awo onjẹ, bẽni iya mi ti ṣe õgun nã fun mi lati isa oku wipe bi enia ba fi õgun buruku si inu onjẹ fun mi alangba yio sa jade ninu awo nã, nigbati eyi si ri

bẹ̀ mo ki ọmọ ọdọ mi mọlẹ mo ko igi bo o, mo ni ki o jẹwọ ibiti o ti ri õgun si onjẹ fun mi. Nigbati mo lu u dãdã o jẹwọ, o ni Ifẹpinya ni o mu u fun on. Mo bẽre bi õgun nã ba kù o si wi fun mi pe o kù.

"Nigbati o di ọjọ keji mo ranṣẹ si Ifẹpinya ki o wa ba mi ṣire o si wa. Nigbati o de mo ni ki ọmọ ọdọ mi fi õgun ti o fi ranṣẹ si onjẹ on pãpã onitọhun si ṣe bẹ̀. O fẹrẹ má iti ijẹ okele meji nigbati inu ti gbe e, nigbati o si di pe o nyi kiri ni ilẹ mo wi fun u ki o mã lọ si ile, inu nã l'o si run u pa.

"Ṣugbọn ibanujẹ ni iku Ifẹpinya tun wa jẹ fun ọba nitori o di ọmọ meji ti o ku fun u leralera nitori ori ibanujẹ ti Ifẹpade l'o wà ti eleyi tun wa ṣẹlẹ. Idãmu pupọ ni nkan wọnyi jẹ fun ọba ara rẹ̀ ko si le mọ, o bẹrẹsi rù, ẹniti o ba si ri i pãpã yio mọ pe lãlã wà fun u.



## ÌTÁNFORÍTÌ TI NGBE INU IHO ILẸ.

"Nigbati o di oṣu kẹta ti Ifẹpinya ku, ọba pe mi ni owurọ ọjọ kan, nigbati mo de ọhun o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni .

"'Ireke-onibudo, emi ni mo pe ọ, pipe ti mo si pe ọ loni iwọ nã ni mo le ṣe bẹ̀ pe ni ilẹ yi, nitori iwọ nikan l'o le ṣe nkan ti mo fẹ ran ọ. Ki a to ri erin o di igbo, ki a to ri ẹfọn o di ọ̀dàn, ki a to ri ẹniti o mã ṣe bĩ rẹ o di ọrun alakeji. Ọdọ abami ẹda kan ni mo fẹ ran ọ, irin ibẹ yio si gbà ọ to oṣu meji gbako ki o to le pada de, sibẹ mo fẹ ki o lọ fun mi, ọdọ ẹniti mo fẹ ran ọ ni ẹniti njẹ Itanforiti ti ngbe inu iho ilẹ. Olõgun ni Itanforiti ọlọgbọn si ni, ko si olõgun rẹ̀ ko si si ọlọgbọn rẹ̀ lode aiye. Nkan ti mo fẹ ki o ba mi ṣe lọdọ rẹ̀ ni yi, mo fẹ ki o lọ ba mi gba nkan ti ng o lo fun aisan mi yi, nitori lati ọjọ ti ọfọ ti ṣẹ̀ mi ara mi yì ko jẹ ara, mo nrọju jade ni, eleyi ni yio jẹ iṣẹ kini ti o mã ṣe fun mi lọhun, ṣugbọn iṣẹ keji ṣe pataki ju ti ekini lọ, eyini ni pe mo fẹ ki o lọ kọ ọgbọn kun ọgbọn nipa ilu yi, ọna ti a o mã fi ṣe gbogbo nkan ti yio fi mã dara, ọna ti alafia fi mã de ti owo si fi mã wọ ilu yi. Awọn nkan meji yi ṣe pataki lãrin awọn ọmọ enia, ilu ti ko bá ni alafia ko le gbadun owo eyiti ko ba si ni owo ko le ni alãfia pipe. Alafia wo l'o wà ni ile ẹniti ebi npa ? Nitorinã nkan ti mo fẹ ki o ba mi ṣe ni yi, Ireke-onibudo, nko si ṣiyemeji rara wipe o ko ni jẹki oju ti mi ati pe o mã ṣe nkan wọnyi fun mi.'

"Nigbati ọba pari ọrọ rẹ̀ emi nã fun u ni esi mo ni, 'Kabiyesi, agbara wo ni ewurẹ ni nibiti olotu rẹ̀ wà ? Aguntan le wipe on a ṣe bi on ti fẹ niwaju ẹniti o ni i ?

Ẹṣin le gbọn ju oluwarẹ lọ ? — Ẹwọ. Nko le kọ iṣẹ fun yin, nko to bẹ̃, nko tilẹ gbọdọ ni, ẹnyin ni mo duro tì nihin, nitorinã ibiti ẹ ba ran mi ng o lọ. Ṣugbọn kini kan ni, mo ro pe irinajo nã yio gba imura gidigidi nitori ẹniti ngbe inu iho ilẹ kuro ni ẹni kekere. Nitori idi eyi, mo fẹ ki ẹ wa bi enia meji tabi mẹta ti a o jọ lọ mo si fẹ ki ẹ yan awọn bĩ meji nã lãrin awọn oniṣegun ilu, nitori biotilẹjẹpe nwọn ko le wo yin ninu aisan yin yi sibẹ ẹniti o mọ ewe meji tabi mẹta yatọ si ẹniti kò mọ nkankan. Eyiti mo ri ti mo le sọ ni yi, Kabiyesi, ki Ọlọrun bùn yin l'ẹmi.'

"Nigbati mo wi bayi ọba gba imọran mi o ni emi nã ni ki o pe awọn oniṣegun ilu jọ ki nyan ẹniti mo ba ro pe o yẹ ki o ba mi lọ.

"Lọjọ kẹta lẹhin eyi, mo pe ipade awọn oniṣegun mo si ba gbogbo wọn sọrọ mo ni : ' Ẹ ku ijoko ẹnyin janmọ̃, ọrọ pataki kan ni mo pe yin si, iṣẹ nla kan l'o de ti a mã ṣe fun ilẹ yi, ọba l'o si fun mi l'aṣẹ. Mo ro pe ẹ ti le gbọ orukọ Itanforiti ti ngbe inu iho ilẹ ri, Itanforiti ti o gbọn ju gbogbo enia ti o si ni õgun ju ẹnikẹni,—ọdọ rẹ̀ ni a nlọ, a nlọ ki a ba lọ kọ ọgbọn ti ilẹ yi yio fi mã ti ibi giga de ibi giga, ti yio mã ni okiki le ori okiki ti alafia yio si jẹ ipin olugbe ibẹ. Lọna keji a o ri õgun diẹ kọ si eyiti a mọ lọdọ Itanforiti a o si ṣe ilẹ yi lõre nipa bẹ̃, ati pãpã ọba wa. Nitorinã nkan ti a mã ṣe nisisiyi ni pe ki a joko ki a pa ero, bawo ni ẹniti o mã lọ ti mã pọ to, awọn wo ni ki o lọ, ọjọ wo ni ki a si mura ati lọ. Ẹ ku ijoko o.'

"Nigbati mo wi bayi awọn oniṣegun gbà tọkantọkan wipe o yẹ ki a lọ, nwọn pinnu pe ki ẹni mẹta lọ, nwọn si yan mi gẹgẹ bi aṣãju ni irinajo nã. Awọn meji ti nwọn tun yan ni ọkunrin kan ti a npe ni Ero-ọkan ati ẹniti orukọ rẹ̀ njẹ Kùmọ́fẹ̀hìntí. Ero-ọkan ki iṣe





ọmọ ilu Alupayida, o wa ṣiṣẹ nibẹ ni o si ti fi idi mulẹ nibẹ dãdã eti ilu mi ni ilu rẹ̀, oloyelori enia ni. Ṣugbọn Kumọfẹhinti ni ẹniti oriki rẹ̀ njẹ Alágídí-ọkunrin nitori enia lile gbã ni, ọmọ ilu Alupayida ni, ọmọ enia pataki si ni pẹlu ṣugbọn ipanle ọmọ ni, o yan garawa.

"Nigbati a ti pari ipade yi ni mo ti sọ fun ọba, igbanã ni mo si ti bẹrẹsi mura, onirũru awọn adahunṣe l'o wa si ile mi, mo fi ọgọfa ẹiyẹle ṣe ẹbọ ni ikorita, mo fi ọgọta adaba ṣe ẹbọ ni ẹhinkunle, ẽdẹgbẹrin gbẹrẹ ni mbẹ ni àtàrí mi, mo pa ewurẹ mẹsan, mo pa aguntan meṣan, mo pa pẹpẹiyẹ meṣan ki ọhun ba sàn fun mi. Mo si ṣe sarã pataki mo pe ogunlọgọ ọmọde ki nwọn wa jẹun ni ile mi, mo ṣe etutu fun oṣo, mo ṣe fun ajẹ, mo si bẹ awọn anjọnnu gbogbo. Lẹhin ti mo mura bayi tan mo da ọjọ lilọ wa.

"Awọn ti a jọ nlọ nã ti mura bi emi, nigbati ọjọ lilọ wa si ku ọla a lọ si ọdọ ọba ni ãfin a ki i o digbõṣe.

"Ile mi ni awọn meji ti a jọ nlọ sun mọju ọjọ nã igbati akukọ iṣãju si ti kọ ni ọjọ keji ni a ti ko ẹsẹ si ọna. Emi mu ida ti iya mi fun mi lọwọ mo fi i si inu àkọ̀ rẹ̀ mo gbe e kọ apa, Ero-ẹhin mu ọbẹ oloju meji si inu apo rẹ̀, Kumọfẹhinti gbe kùmọ̀ lọwọ. Awọn nkan ti a fi ṣe ọkunrin si ọwọ ko ju iwọnyi nã lọ.

"Ọna ti a o rin kò tobi, ọna kekere ni, on ni a o si rin titi de ile Itanforiti fun odidi oṣu kan, inu aginju ni a o mã ba lọ, awọn ẹranko buruku ati awọn abami ẹda si wà loju ọna niwaju wa, gbogbo iwọnyi nã l'a si mọ ki a to mura.

"A ko onjẹ diẹ si inu apo ti a o mã jẹ lọna ṣugbọn òjò kan rọ̀ lọjọ ti a kuro ni ile ti o pa wa gãn ni, eti wa fẹrẹ di, gbogbo eweko tutu nini, àgbàrá ojo dagun si oju ọna lọ, àbàtà ba wa l'ẹsẹ gbogbo, aṣọ ara wa rẹ, otutu nla bẹrẹsi mu ni, a npa ehin keke, bi atẹgun si

ti nfẹ ni omi ngbọ̀n le ni lori. Igbati a si tun tilẹ rin diẹ ni a ba igi nla kan ti o wo di oju ọna, a tun nilati wọ igbo ki a ja oju ọna niwaju, bẽni ibiti a tun wọ kun fun igi ẹlẹgun gbogbo, ẹgun si gun ni lara yẹ́lẹyẹ̀lẹ.

"Nkan ti a le pe ni iyọnu lọjọ ti a kuro ni ile nã ko ju eyi lọ, ko si si nkankan ti o tun dà wa lãmu fun ọpọlọpọ ọjọ lẹhin nã, ṣugbọn nigbati o di ọjọ keje a de oke nla kan ti orukọ rẹ̀ njẹ Hílàhílo. Oke nã buru gidigidi, ẹ̀gbẹ rẹ̀ ndan bi igbati gbẹnagbẹna ba fa igi, oke pãpã kò si duro si oju kan o nmì siwa sẹhin o nti enia si ihin sọhun bi oluwarẹ ba ti ngun u lọ. Mo fẹrẹ tàkìtì ọbọ nibiti mo ti ngun oke Hilahilo lọ. Igbati o ṣe a ri oke nã o gbina ni isalẹ o si njo bọ lọdọ wa, bẽni oke ni yi, a kò le yara gun u, a si fi ara wa silẹ fun iku. Nigbati o ṣe Ero-ọkan wi fun wa pe Anjọnnu ibẹ l'o nfẹ yọ wa lẹnu, mo si wo oju ọrun mo ke si Ọlọrun Ọba, mo ni ki O yọ wa ninu iyọnu nã, a ko ṣe ẹnikẹni ni ibi, a ko si ni ibajẹ kan lọkan nibiti a nlọ, mo ni : 'Iwọ Ọlọrun ọrun ti O da igi ti O da eweko ti O da kokoro ti O da awọn ẹranko, ti O si fi awa enia si itọju wọn, Iwọ nã l'o da oke yi, jọwọ pa ina ijamba odo ẹsẹ wa, ti ilẹkun ibanujẹ ti o nfẹ yọju si wa, doju ija kọ bilisi nitori wa. Pa ina ti nbọ ni isalẹ yi, Olodumare pa a, pa ina nã, Ẹlẹda pa a, pa ina nã, Ẹni Iyanu pa a, pa ina nã, Alewileṣe, maṣai pa a fun wa. Maṣe jeki a ku si ori oke yi, má jẹki oke Hilahilo pa ni rẹ́ ninu aiye, maṣai jẹki a de ibiti a nlọ, má si ṣai jẹki a pada de ile dandan.'

"Bayi ni mo sọ, nigbati o si ṣe a ri i pe ina nã bẹrẹsi ku a si ngun oke nã lọ. Nigbati o pẹ a gun u de ori, ṣugbọn dipo ki o rẹ̀ wa nigbati a gun u tan ṣe ni ara wa tubọ le koko, bi a ri oke meji bẽ si i ki a mã gun u ni.

"A tun kọju si ọna wa, a nlọ, nigbati o si di ọjọ kẹfa





"Mo fẹrẹ tàkìtì ọbọ nibiti mo ti ngun oke Hilahilo lọ."

lẹhin eyi a de ilu kan. Ilu nã yatọ si gbogbo ilu ti mo ti ide rī, idi iyatọ rẹ̀ si ni pe ko si woro obinrin kan nibẹ, gbogbo awọn ti a ba pade ọkunrin ni wọn, ọba ibẹ ni ẹniti njẹ Gbaiyegbọrun nitori ojojumọ ni imã lọ si ode ọrun. Ilu nã wà gẹgẹ bi apẹ̃rẹ ti Ẹlẹda ṣe lati fihan bi aiye ọmọ enia iba ti ri bi ko ba si obinrin. Bi enia ba nfẹ ọmọ ni ilu nã a lọ si ọdọ Gbaiyegbọrun a sọ fun u a si fi aworan ara rẹ̀ fun u pẹlu, gbaiyegbọrun a mu aworan nã lọ si ode ọrun a si mu ọmọ kan bọ ti nwọn ṣe lati ọrun ti o jọ ẹni nã. Ṣugbọn mo ṣe akiyesi wipe ifẹ ti o wà lãrin awọn obi si ọmọ nibẹ ko ju kekere lọ awọn ọmọ ko si ngbọran si obi wọn lẹnu, nitori awọn ti o ni wọn kò ṣe ãpọn ki o to ri wọn, nwọn ko mọ iyi ọmọ nitori nwọn ko ni ọwọ ninu bibi wọn, igbega nla gbã ni fun awọn ọmọ enia nigbati Olodumare fun wọn ni agbara ati mã bimọ fun ara wọn, eyini ni pe Olodumare fun wọn ni aye ati ni ọwọ si dida enia si ode aiye.

" Ṣugbọn kini kan ti mo tun ṣe akiyesi ni ilu awọn ọkunrin yi ni pe nwọn ya ara oko, nitori ọpọlọpọ ni o nsan ibantẹ kiri lãrin ilu ihõho si ni ogunlọgọ wà ninu ile wọn.

" O si tun ya mi lẹnu lati ri i pe owo kò pọ ni ilu nã to nitori nwọn ko ri aye ṣiṣẹ, nwọn nilati wa onjẹ ara wọn ki nwọn tọju ile, ki nwọn pọn omi ki nwọn si ṣe onirũru iṣẹ ti obinrin nṣe.

" Ṣugbọn irẹpọ wà ni ilu nã ju bi mo ti ni ero lọ, nwọn ko nfi agbara da si nkan oninkan, nwọn ni itẹlọrun si nkan ara wọn, bi mejilã si ngbe pọ a kò ngbọ ija wọn ju bẹ̃ lọ, ṣugbọn ija a mã de si ãrin wọn lẹ̃kọkan, bi ija ba si ti de ko npẹ di wipe ki nwọn mã lu ara wọn ki ara wọn bo fẹlẹfẹlẹ, omiran a si tilẹ ku patapata ni.

" Ariwo pọ ni ilu nã loju temi nitori bi nwọn ba





nsọrọ ohun wọn a mã le koko bi nwọn ba si nrẹrin ẹrin wọn a mã ta ni leti ṣaṣa.

" Ko si nkan ti o rọ̀ ni nkan wọn, ijo wọn le, orin wọn le, ìlù wọn le, bi nwọn ba nṣire, ire lile ni nwọn mã nṣe, ṣe ni nwọn a mã le ara wọn ka ti nwọn a mã lu ara wọn.

" Nwọn nṣe ọrẹ ara wọn lõtọ ṣugbọn ko si iru ifẹ ijinlẹ ti o mã nwa lãrin ọkunrin ati obinrin meji nigbati nwọn ba nfẹ ara wọn, ifẹ ti imã ru bo wọn bi ọti, ti imã pa wọn bi ẹmu, ti o si mã nmu ki tọkunrin tobinrin di afọju ti nwọn kò nle ri nkan ti o dara mọ eyini ko si ni ilu nã.

" Ṣugbọn ilu nã mọ tonitoni, nwọn ro gbogbo oju ọna ãrin ilu nwọn si ṣe Titì si ilu nã kiri, bi ilẹ ba si ti mọ ni olukuluku nmu ohun igbalẹ rẹ̀ ti o ngba ita. Ṣugbọn nwọn ko nṣe eto ile wọn dãdã, gbogbo rẹ̀ a ri gbúrugbùru, nwọn a gbe aga si ibiti nwọn ri, nwọn a fi fila kọ ibiti o wù wọn, nwọn kò si nmọ ibiti nwọn ba fi nkan si, ojojumọ ni nwọn nwa nkan wọn kiri.

" Onjẹ wọn dara ni ilu nã ṣugbọn ọbẹ wọn ko dun ju bẹ̃ lọ. Ṣugbọn nigbati mo wo gbogbo nkan ti nwọn nṣe ni ilu nã mo wa ri i pe bi ko ba si obinrin laiye aiye kì ba ti dùn ju bẹ̃ lọ, gbogbo nkan iba le koko ko ba si ti si nkan ti o le ṣe etutu si nkan lile aiye, ẹwa ọmọ enia kì ba si ti mã yọ, awọn enia ko ni bikita ati mã tọju ara wọn, nitori bi ẹgbẹrun ọkunrin ba pejọ ti ko ba ti si obinrin kan nwọn le mã rin ihõho loju ara wọn.

" A kuro ni ilu nã lọjọ kẹta a si ra onjẹ diẹ lọwọ fun irinajo wa. Ko pẹ pupọ ti a kuro yi ti a de ibiti orukọ rẹ̀ njẹ Aginju Irẹwẹsi nibiti oju wa ti ri nkan. Bi a ti rin diẹ ni okunkun dede ṣu ti a ko mọ ibiti a le gbe ẹsẹ si mọ, bi a si ti ntanna si atupa ni atupa nku bẹ̃ni a ngbọ igbe awọn iwin bi nwọn ti nke si ara wọn.

Ọkan ninu wọn tilẹ gbe ina le ori o nbọ niwaju wa igbati o si rin diẹ a ko ri i mọ afi igbati a tun wo ẹhin ti a tun ri ina ori rẹ, bi o ti ṣe kọja wa ti a ko mọ ti oju su mi. Nigbati o ṣe a de ibikan ti a ti riran diẹ bayi ṣugbọn bi a ti de ibẹ ti a wo iwaju ni a ri iwin kan ti o ni iwo kan lori ti o nbọ niwaju wa. Bi o ti yọ lọkankan l'o ti na ọwọ meji gbalaja bi ẹnipe o nfẹ ka wa mọ ibikan ki a má ba salọ, ẹru ba ni a si nwo ara wa loju yala wipe ki a salọ ni o tabi ki a duro de e. Kumọfẹhinti l'o kọ sọrọ nigbati o si sọrọ o ni on o ba iwin nã ja ni, o mura o bọ siwaju awa nã tẹle e, iwin nã nbọ lọdọ wa, nigbati o kù diẹ ki o de ọdọ wa o ni: 'Tani ẹnyin wọnyi? Kil' ẹ gbẹkẹle? Nibo l'ẹ ti nbọ? Nibo l'ẹ nlọ? Ẹ pade ijangbọn loni, ẹ ko ẽmọ lọna, ẹ da aṣọ wahala bora, ọwọ ibanujẹ tẹ yin, ijamba ṣe yin, ẹ rin lọjọ ebi npa ọna, oni ni ọjọ ijangbọn, oni ni ọjọ opin, oni ni õrun ti là loju yin mọ, ẹ ti bọ si takute, pipa ni mo mã pa gbogbo yin jẹ.'

" Nigbati o wi bayi a ko sọrọ kan, ṣugbọn gbogbo wa mura. Kumọfẹhinti l'o kọ kọlu u, nwọn si ja ija nã tobẽ ti mo le wi fun ọ pe nko ri iru rẹ ri, Kumọfẹhinti jẹ alagbara ọkunrin iwin nã si le. Nigbati o mu Kumọfẹhinti o bẹrẹsi ti i lọ si ibi okuta ki o ba fi ori rẹ na okuta ṣugbọn Kumọfẹhinti gba ara rẹ, o gbe ẹbọra nã ni ẹsẹ ọtun onitọhun ntiro, igbati o ṣe o ka mọ Kumọfẹhinti l'ọrun o si fun u ni ọrun bi ẹnipe o fẹ pa a, o si pẹ diẹ ki onitọhun to le ja ọwọ rẹ kuro ti o sọ ọ si iwaju, igbati o si tun de ọhun o na iwo ori rẹ si iwaju o nsare bọ lọdọ Kumọfẹhinti o nfẹ fi iwo nã gun u pa, onitọhun nã si fi gbogbo agbara gbe kumọ rẹ o na a mọ ọ ni iwo. Eleyi dun iwin, nã o si ta gẽgẽ, akoko nã ni emi nã wa fa ida mi yọ ti mo pa gũru si iwin nã ti mo ṣa a mọ ọ ni ẹhin ọrun. Ada yi ran a dãdã





ṣugbọn dipo ẹjẹ omi l'o jade lara rẹ, mo tun ṣa a ni omiran mo tun tẹ ọwọ mọ ọ mo nṣa a Kumọfẹhinti nã nlu u ni kumọ rẹ, nigbati o pẹ, o ṣubululẹ, ṣugbọn bi o ti ṣubu bayi a ko tun ri i mọ, ibiti a ri mọ si ni eyi, o ṣubu loju wa, ṣugbọn kò dide loju wa.

" Nigbati o di ọjọ karun ti a kuro ni ilu awọn ọkunrin a de ilu awọn obinrin nibiti ko si ọkunrin kan rara. Orukọ ọba wọn ni Ẹiyẹ-ọrun, ọna kannã ti awọn ọkunrin fi ngba ọmọ lode ọrun nã ni awọn obinrin fi ngba ọmọ wọn.

" Awọn obinrin ti mo ri wọnni ko fi ara wọn pamọ bi obinrin rara, pupọ ninu wọn l'o nrin ihõho ninu ile wọn, awọn wunndia gbogbo nro aṣọ ni, nwọn ko nwọ buba nwọn ko si nbikita nigbati aṣọ wọn ba tu ti nwọn ba ntun u ro ni igboro.

" Ṣugbọn o ya mi lẹnu lati ri i pe gbogbo nkan ti ọkunrin nṣe ni awọn nã nṣe, oko wọn tobi, o nilãri, iṣu wọn ta, agbado wọn yọ ọmọ erẽ wọn si so.

" Nwọn nṣe iru ire ti ọkunrin nṣe, nwọn nsare, nwọn nfo, nwọn ngun ẹṣin, nwọn ngun igi.

" Ni ilu nã, fãri wọn ju ti ilu awọn ọkunrin lọ, ṣugbọn nwọn gbadun ati mã sọrọ ara wọn lẹhin kiri, ninu gbogbo awọn ti a ba pade nibẹ ṣàṣà ni ẹniti ko sọrọ ẹlomiran loju wa.

" Ṣugbọn o ya mi lẹnu pe ile wọn ko mọ bi mo ti ro pe o yẹ ki o mọ to, idi rẹ si ni pe nwọn ko ri aye ṣiṣẹ ile niwọnigbati nwọn ti nṣiṣẹ ti o yẹ ki ọkunrin ṣe mọ iṣẹ wọn, ilu wọn kun fun koriko, o si dabi ẹnipe iṣẹ nã pọ ju bi nwọn ti lagbara mọ. Aṣọ wọn kò ni ẽri ṣugbọn nwọn le di ẹru pupọ si iyãra wọn, bi nwọn ba si nlọ si idalẹ nwọn a di ẹru kítikìti, ko si nkan ti nwọn ko ni di tan, mo ri eleyi ninu ile ti a wọ̀ si nitori obinrin kan lọ si idalẹ nibẹ loju wa.

" Ṣugbọn nwọn le bẹru pupọ, bi ilẹ ba ti ṣu diẹ nwọn ko nle nikan rin lọ si ibikibi, pupọ ninu wọn ko si le pa ejo bi o ti wù ti ejo nã kere to, ṣugbọn awọn diẹ wà nibẹ ti nwọn npa ejo ti ko ba tobi ju bẽ lọ.

" Ẹda ti o tete nsọkun ni wọn, nkan kekere le mu agbalagba wọn mã kigbe. Ṣugbọn ọpọlọpọ ãnu ni mbẹ ni oju wọn, bi nkan ba ṣe ẹnikan nwọn kò ni ṣai ba a kẹdun nwọn ko si ni ṣai lọ si ile oluwarẹ lọ ki i.

" Bi oniwatutu ti wà nibẹ nã ni a ri oniwa lile, mo ṣe akiyesi bi nwọn ti ṣe nlo ọmọ ọdọ wọn. Ẹlomiran nlo ọmọ ọdọ bi ẹnipe ọna iku rẹ ni o nwa, omiran si nlo o bi ẹnipe on ni o bi i, a fun u ni iṣẹ ti ọwọ rẹ ka, a fun u ni onjẹ ti o dara.

" Ofin wọn ko lagbara ju bẽ lọ nwọn ki ika awọn ti o ba nṣiṣẹ ilu si bi o ti yẹ, nwọn a mã lu ofin bi nwọn ti fẹ ti nwọn ba si sọ fun wọn nwọn a dà a si ija.

" Ṣugbọn ilu nã dara pupọ fun kini kan, olufọkansin ni gbogbo wọn, awọn onigbagbọ ki ipa Ṣọ̃ṣi jẹ, awọn onimọle nlọ si Mọṣalasi lakoko, awọn abọriṣa si nlọ si ile oriṣa wọn, ko si ẹnikan ninu awọn obinrin nã ti ko gba nkankan gbọ.

" Nigbati mo wo gbogbo wọn ti mo si tun wo ohun ti mo ri ni ilu awọn ọkunrin mo ri i pe ọgbọn Ẹlẹda pọ pupọ ti o da ọkunrin ati obinrin si ode aiye, awọn ọkunrin duro bi egungun awọn obinrin si duro bi ẹran ara ni ara enia. Laisi egungun ara ko le ṣe nkan, laisi ẹran, egungun ko le ṣe nkan.

" Ọjọ kẹta ti a de ilu awọn obinrin ni a fi ibẹ silẹ ti a si tun mura si irinajo wa si ile Itanforiti ti ngbe iho ilẹ.

" A rin titi a ko ri nkankan fun odidi ọjọ mẹsan lẹhin eyi, ṣugbọn nigbati o di ọjọ kẹwa a de ibikan ti orukọrẹ̀njẹ Aginju Mimọ, o ku ọjọ kan ki a de ibiti a nlọ.





" Aginju Mimọ yi kun fun ẹ̀rù gidigidi, awọn igi titobi wà ni apa ọtun ati apa osi oju ọna, nwọn si gbá idi wọn mọ tonitoni, ko si ẹiyẹ tabi ẹranko kan nibiti a nsọrọ rẹ̀ yi, gbogbo ibẹ si dakẹ minimini bi ọganjọ oru. Bi a ti nlọ a ri ọkunrin kan, o duro si ẹba ọna, nigbati a de ibẹ a ki i on nã si ki wa, bi a si ti woye pe o nfẹ ṣe nkankan a duro a nwo o, o si mu eso igi kan o gbin i loju wa, oju wa nã ni igi yi si ṣe hu ti o ga soke ti o si so eso. Nigbati o ṣe, awọn eso wọnyi bẹrẹsi wọ̀ silẹ bi nwọn si ti nba ilẹ ni nwọn nbẹ́, igbati eyiti o kọ balẹ bẹ ejo kan ti inu rẹ̀ jade o si bu ọkunrin ti o gbin i jẹ, ọkunrin nã bẹrẹsi kerora, igbati eso keji bẹ o di akẽkẽ meje nwọn si bẹrẹsi ta a, igbati ẹkẹta si bẹ, kiniun kan jade ninu rẹ̀ o pa ọkunrin nã, igbati kiniun nã jẹ eyiti yio jẹ lara rẹ̀ tan eso kẹrin bọ silẹ, nigbati o si balẹ, o bẹ, ọkunrin kan si jade lati inu rẹ̀, bi o ti jade o ko egungun ẹniti kiniun pajẹ nã o bo o mọlẹ o si mu iwe kan o kan a mọ iboji rẹ̀, ohun ti o wà ninu iwe nã ni yi: ' Eleyi gbin eso ibi, o ka ibi, o pa ero ibajẹ ti ọmọnikeji, on nã di ẹni ibajẹ.'

" Nigbati a tun rin diẹ a ri ọkunrin miran ti o mu eso igi miran loju wa, o gbin i, were igi hù, were o dagba, were o so eso, igbati o ṣe, eso kan bọ silẹ o bẹ, bi o ti bẹ ọmọde kan jade, bi o si ti jade o kọju si ọkunrin nã o tẹriba o ni, ' Iwọ l'o tọju mi ninu aisan mi ijelo, mo di tirẹ. ' Ikeji ninu eso nã tun balẹ, o tun bẹ, bi o si ti bẹ ni ọmọ miran jade o tun kọju si ọkunrin nã o tẹriba o ni, ' Igbati awọn obi mi wà ni gbese iwọ l'o ran wọn lọwọ ti nwọn yọ, mo di tirẹ.' Eso kẹta si tun wọ̀, o bẹ, ọmọ kan tun ti inu rẹ̀ jade, o tun kọju si ọkunrin yi o tẹriba o ni, ' Owo ti o na fun mi nigbati mo nlọ si ile iwe ki iṣe kekere, mo di tirẹ.' Nigbati o ṣe ni awọn ọmọ mẹta yi gun igi nã lọ ti nwọn ja eso

kõkan funra wọn—ekini fọ tirẹ̀ mọlẹ ile nla kan yọ jade, ekeji fọ tirẹ̀ o di ogunlọgọ ohun ọsin, ẹkẹta fọ tirẹ̀ mọlẹ apoti owo gõlu, fadaka ati diamondi si kun ilẹ kítikìti. Lẹhin eyi, nwọn kọju si ọkunrin nã nwọn ni, 'Eyi ni nkan ti o gbin, o digba.' Bi nwọn si ti wi bẽ tan ilẹ la ẹnu o gbe wọn mì.

"Bayi ni nwọn wọ ilẹ lọ, ọkunrin nã si ko awọn nkan wọnni o bẹrẹsi gbe wọn ni ọkõkan wọ ibikan bayi lọ, awa nã si kọju si ọna wa a nlọ.

"Nigbati a rin diẹ a pade ọmọbinrin kan ti o wọ aṣọ funfun. O ki wa awa nã si ki i, o bẽre ibiti a nlọ a si sọ fun u pe ile Itanforiti ni, ati pe bi o ba mọ ọna ki o ṣe apejuwe fun wa. O dahun o ni: 'Ẹnyin ọmọ enia, ile Itanforiti ko jinnà pupọ mọ ṣugbọn ki ẹ to de ibẹ ẹ o lo ọgbọn yin dãdã. Bi ẹ ba ti le de ile Itanforiti ko si ifoiya mọ, nitori alãnu ẹda ni on nṣe, ṣugbọn ati de ile Itanforiti ni nkan. Laipẹ ẹ o de orita ọrun, ẹ o si ri ọna ọrun lapa ọtun, ẹ o ri ọkunrin kan ti o wọ aṣọ funfun ti o duro si oju ọna nã. Bi ó ba ti bi yin pe ẹni aiye ni yin tabi ẹni ọrun ki ẹ fesi pe ẹni aiye ni yin. Bi o ba si bi yin bayi pe ẹ nfẹ di ẹni ọrun bi, ki ẹ da a lohun pe ẹni aiye l'ẹ fẹ ṣe. Ẹ o mã ri ogunlọgọ enia ti yio mã yà ba ọna ọrun lọ. Ẹ ko gbọdọ ki wọn, bi nwọn ba si ki yin ẹ ko gbọdọ dahun. Bi nwọn ba ti nde oju ọna nã ni nwọn o mã gbe wọn le ìwọ̀n loju yin, nwọn o si mã gba iwe lọwọ ẹniti o duro si ọna nã, iwe bi ẹṣẹ wọn ba ti wuwo to ni eyini, on ni nwọn o si fi da wọn lẹjọ lode ọrun. Ẹ nilati ṣọra gidigidi nipa orin ti awọn ara ọrun nkọ, bi ẹ ko ba ṣọra ẹ ko ni mọ igbati ẹ ya si ọna nã.

"'Bi ẹ ba kuro ni orita ọrun tan ẹ o mã ri awọn oyin ti nfo, bi nwọn ba bà le yin ẹ maṣe pa wọn nitori bi ẹ ba pa ọkan ninu wọn tita ni gbogbo wọn o ta yin pa.





"'Nigbati ẹ ba si yọ si Ile Itanforiti, ẹ o ri ogunlọgọ òdòdó ti nwọn hù ti nwọn lẹwa gidigidi. Ki ẹ lọ si ibiti nwọn ba pọ si jù, nigbati ẹ ba de ibẹ ẹ o ri oju ọna ti o ba iho ilẹ lọ; ṣugbọn ẹ o ri ejo kan loju ọna nã ti nṣọ ibẹ, bi ẹ ba ri i ṣe ni ki ẹ di i ni ọrun mu ki ẹ rọra gbe e si apakan ẹ maṣe wipe ẹ mã pa a o. Mo ro pe eyiti mo le sọ mọ nã ni yi, nko ranti ju eyi lọ ki Ẹlẹda yin ṣe alatilẹhin yin.'

"Bayi ni ọdọmọbinrin yi sọ a si dupẹ lọwọ rẹ̀, a kọju si ọna, a nlọ. Nigbati o ṣe a ri i pe Aginju Mimọ ti a nla bọ tubọ nba ni lẹru si i, aiya wa bẹrẹsi ja pupọ-pupọ ọkan wa nlù kìkì bi ẹrọ inu mọto. Awọn igi ti a nri l'o tubọ mu ibẹru nã wa, gbogbo wọn l'o bẹrẹsi funfun bi ẹnipe aṣọ funfun ni ara wọn, o si dabi ẹnipe nwọn nkuro nibiti nwọn hù si nwọn nrin kiri. Nigbati a rin diẹ, a de orita ọna ọrun a si ri awọn ọpọlọpọ enia ti nwọn ngba iwe lọwọ ọkunrin ti o wọ aṣọ funfun ti o duro si oju ọna nã.

"Nigbati a de ibẹ ọkunrin nã bi wa, o ni: 'Ẹni aiye ni yin tabi ẹni ọrun?' A si dahun a wipe, 'Ẹni aiye ni wa.' O tun bẽre o ni, 'Ẹ nfẹ di ẹni ọrun bi?' A si tun da a lohun a ni, 'Bẹ̃kọ, ẹni aiye l'a fẹ ṣe.' O dahun o ni, 'Ẹ kuro niwaju mi.' Awa nã si nlọ, ṣugbọn mo ṣe akiyesi ọna ti o lọ si ode ọrun yi pe nkan ti nwọn fi ṣe oju ọna nã dabi ọkẹ aimoye irawọ ti nwọn fi eti wọn ko ara wọn, o ndan tobẽ ti nko ri nkan ti o dan tobẽ ri, o le fọ enia loju bi oluwarẹ ba wo o jù, nko le wo ọna nã lọ si iwaju, a kọju si ọna tiwa. Bi a ti rin bi ẹsẹ bata mẹfa ni a gbọ orin kan ti o dabi ẹnipe ohun enia yipada o di agogo ti ndun gbinrin-gbinrin. Mo duro diẹ, bi mo si ti ṣe bẽ ṣe l'o dabi ẹni ki nmã lọ si ibiti orin nã ti nwa, igbati mo si mã bojuwo ẹhin Kumọfẹhinti ti pada, emi nã si nfẹ pada ki Ero-

ọkan to di mi mu. Emi ati Ero-ọkan bẹrẹsi ke si Kumọfẹhinti ṣugbọn ko da ni lohun rara, o lọ ba ọkunrin ti o wà loju ọna o ni ki o jẹki on wọle, oju wa bayi ni nwọn si ṣe gbe e le ori iwọn ti nwọn fun u ni iwe pe ko gbọdọ lọ si ibiti o ti ngbọ orin didun nì, nwọn ni ki o lọ si apa osi kan bayi, o si wọ inu igbo ibẹ lọ. Bayi ni a ṣe ti a ko ri Kumọfẹhinti titi di oni oloni. Emi ati Ero-ọkan duro titi a ko ri ẹnikẹta wa mọ, nigbati o si pẹ, a kọju si ọna a nlọ.

"A bẹrẹsi rin lọ ni oju ọna, Aginju Mimọ wà lapa ọtun wa, nigbati o si di oju alẹ, a fi aginju nã silẹ, nigbati a kuro nibẹ tan ni a yọ si ogunlọgọ awọn oyin ti nwọn nfo yi wa ka ti nwọn si nbà le wa ṣugbọn a kò pa eyikeyi ninu wọn, nwọn ko si ta ni. Igbati o ṣe a kuro lọdọ awọn oyin nã, bi a si ti rin si iwaju diẹ si i a ri i pe ilẹ nṣu, a si sun labẹ igi kan. Ârẹ mu ni pupọ ara wa si wuwo ati pãpã nipa ti Kumọfẹhinti ti a sọnu.

"Nigbati ilẹ mọ lọjọ keji ti a jẹun tan a tun fi ẹsẹ si ọna, igbati o si di ọsan gangan patapata ni nkan bi agogo kan, a yọ si ile Itanforiti. A ri ọpọlọpọ eweko ti o ni onirũru itanna ti o si pọ̀ lọ o gbalẹ to bĩ ki a rin iṣẹju mẹwa ni ìbú ati mẹwa ni gigun. A si wa ṣe akiyesi ibiti itanna nã pọ si jù, igi nla kan bayi wa nibẹ ti o ni itanna pupọ, ibẹ ni a lọ, nigbati a de ibẹ a ri ilẹkun kan ti o pade mọ ilẹ a si ri ejo nla kan ti o gbe ori le e. Ero-ọkan l'o si na ọwọ ti o rọra di ejo nã ni ọrun mu ti o gbe e si apakan. Lẹhinnã, a ṣi ilẹkun a si ri àtẹ̀gùn kekeke ti o ba iho ilẹ lọ. A bẹrẹsi sọkalẹ lori àtẹ̀gùn yi.

"Nigbati a de isalẹ a ba ara wa ninu ãfin nla kan a si ri ọmọbinrin arẹwa kan. Bi o ti ri wa, o ju ọwọ si wa pe ki a duro a si ṣe bẽ. Lẹhinnã o wa si ọdọ wa





o ni: 'Iwin ni yin tabi enia ?' A si fesi a ni, 'Enia'; o tun bẽre o ni: 'Kini idi rẹ̀ ti ẹ fi wa si 'hin ?' Mo si dahun mo ni, 'Ọgbẹni Itanforiti ni a wa wa, ọba ilu Alupayida l'o ran wa si i, nitorinã bi ẹ ba mọ ibiti o wà ẹ jọwọ ẹ maṣai sọ ibẹ fun ni.' Nigbati mo wi bayi o dahun o ni: 'Ọmọ enia ṣoro, ọlọgbọn ṣọṣoro kun inu wọn, ko si ibiti nwọn ko le wa idi nkan de, ko si ọna ti nwọn kò le lo ọgbọn wọn gbà, ẹlomiran nwa idi nkan ki o ba le ri aye ri ọmọnikeji fin, bi o ba ri i fin tan ki o mã fi ẹnu ba a jẹ kiri, asẹhinwa asẹhinbọ ki ó wa ọna ati fa a si inu ọgbun. Ọmọ araiye ṣoro, ẹ jẹki nwọle ki nsọ fun Itanforiti baba mi, ki o bẽre lọwọ awọn anjọnnu bi o ba yẹ ki ẹ ri i tabi ko yẹ.'

"Nigbati o wi bayi, o wọ iyãra kan lọ, nigbati o si pẹ diẹ a ri ogunlọgọ awọn ẹiyẹ, nwọn ti iyãra nã jade nwọn si bà si ẹgbẹ ogiri kakiri ibiti a duro si nwọn kọju si wa nwọn nwo wa. Nigbati o pẹ diẹ awọn ẹiyẹ nã dide nwọn tun wọ iyãra ti nwọn ti jade.

"O pẹ diẹ lẹhin eyi ni ọmọbinrin nã jade si wa ti o ni ki a tẹle on, a si tẹle e, a wọle. Nigbati a de ọhun a ri i pe ibẹ tobi pupọ a si ba Itanforiti lori aga ni ibikan bayi ti o ga diẹ lapa oke. Itanforiti jẹ ẹda ti o ba ni lẹru pupọ. Ori enia ni ori rẹ̀, bẽ si ni ẹ̀gbẹ́ rẹ̀, ṣugbọn ẹsẹ rẹ̀, ti malũ ni. Ori rẹ̀ pá lãrin, awọn irun diẹ ti o si hù si isalẹ ori nã ti di funfun.

"Nigbati o ri wa, o rẹrin o ni ki a mã bọ lọdọ on. Igbati a si de ibiti o joko si o ni ki nwọn gbe aga fun wa ki a joko si iwaju on.

"Lẹhin ti a joko tan o bẹrẹsi ki wa o ni, 'Ẹ ku abọ, ẹ ku irin, ẹ ku lãlã gbogbo, ẹ ku wahala, ẹ ku ewu oju ọna, ẹ ko ri wahala ni Oke Hilahilo bi ? Njẹ ẹ kọ ọgbọn diẹ ni ilu awọn ọkunrin ? Ẹ ko ṣe akiyesi ni ilu awọn obinrin bi ? Bawo ni ẹ ti ṣe kọja ọna ode ọrun ?

Njẹ orin ibẹ ko fa yin mọra ? Ẹ kãbọ, ẹ kãbọ, ẹ ku irinkiri ode aiye, ẹ ku inira ibẹ, ẹ pẹlẹ, ẹnyin ọmọ Oduduwa, ẹnyin iran Ọkanbi, ẹnyin ti o ti apa ila õrun wa.

"'Emi ni Itanforiti, ẹniti ngbe inu iho ilẹ, ọjọ pẹ ti mo ti de inu aiye: ki Oduduwa to ko ẹnyin ọmọ Yoruba de ibiti ẹ wà yi, emi ti mbẹ. Ọgbọn ti Olodumare fun mi pọ, ọjọ mẹjọmẹjọ ni mo si nlọ si ode ọrun lati juba Ọlọrun Ọba, ko si nkan ti ẹnikan nwa ninu aiye ti ko le ri bi o ba ti gbẹkẹle Ọlọrun Ọba. Ki ẹ to kuro lọdọ ọba yin ni mo ti ri yin, bi ẹ ti nbọ ni mo si ti mọ pe ẹ nbọ, ohun ti ẹ nba bọ ko si ṣe ipamọ fun mi. Ng o yanju gbogbo rẹ fun yin ki ẹ to lọ. Mo fẹ ki ẹ lọ jẹun nisisiyi, nitori ebi ki iwọ inu ki ọran miran wọ ibẹ, ẹ tẹle ọmọ mi nisisiyi ki o mã mu yin lọ si ibi onjẹ.'

"Nigbati o pari ọrọ rẹ ọmọbinrin ti o mu wa de ibẹ ni ki a tẹle on a si tẹle e, o mu wa lọ si iyãra kan ni apa oke ile nã, nigbati a si de ibẹ o gbe ẹkọ pẹlu ọbẹ ẹran fun wa a si jẹ. Ọbẹ nã dara o si ya ni lẹnu pe nwọn le se ọbẹ ti o dara bẽ nibẹ. Ibiti a ti njẹun ọmọbinrin nã ko sọrọ lile bi o ti ṣe nişãju mọ, kàkà bẽ ire l'o nba wa ṣe ti o nbẽre onirũru nkan lọwọ wa. O bẽre bi ilu wa ti ri, bi alafia ti wà nibẹ to, ati bi o ti jina to si ibugbe awọn, gbogbo iwọnyi ni a si sọ fun u.

"Nigbati a jẹun tan, a pada si ọdọ Itanforiti o si dide o ni ki a tẹle on ki on mu wa yi ile on po. Ni iyãra ti o kọ mu wa de a ba ejo nla kan ti o ni ori enia ti o si sọrọ si Itanforiti, nigbati nwọn ki ara wọn tan Itanforiti fi wa han a gẹgẹ bi alejo, nigbati o si bẽre bi iwin ni wa tabi enia ti a wipe enia ni wa o poṣe o ni ki Itanforiti mã mu wa lọ nitori ninu gbogbo ẹda alãye ko si ẹniti o korira ejo bi enia.






"Emi ni Itanforiti ẹniti ngbe inu iho ile."

" Awa nã ba kuro nibẹ, Itanforiti si nmu wa lọ. Nigbati o ṣe o mu wa wọ iyãra miran, idẹ ni nwọn s fi ṣe ọṣọ si iyãra nã lati oke de ilẹ, a ri onirũru ere id ti nwọn ṣe ni onirũru ẹranko ni iyãra yí. Itanforit wi fun wa pe a ko gbọdọ fi ọwọ kan eyikeyi ninu wọn nitori bi ọwọ wa ba kan ọkan a o yipada a o di ẹranko ti ọwọ wa kan. Bi o ti wi bayi fun wa tan on nã fi ọwọ kan ere agbọnrin kan were bi o si ti ṣe bẽ ni o yipada ti o di agbọnrin ti on ti iwo lori ṣaraṣara. Igbati o ṣ agbọnrin yi wọ iyãra kan ti o wà ni ẹgbẹ eleyini, igbat a si tun mã ri, Itanforiti ni o tun jade. A bẽre nkan ti iyãra ere nã wà fun o si wi fun wa pe o wà fun awọn ti o ngbe ile on, bi nwọn ba fẹ jade ni àwọ ẹranko nwon lè wa si ibẹ ki nwọn yi ara wọn pada ki nwọn jad lọ, nipa bẽ ẹnikan le yipada si kiniun ki o lọ pa ẹran wa fun awọn.

" Lẹhinnã a jade ni iyãra yi a tun wọ omiran lọ Eyiti a de yi jẹ digi lati oke de ilẹ ko. Itanforiti si mu wa lọ si apakan nibẹ o ni ki a bẹrẹ ki a wọ digi nã nigbati a wo o a ri nkankan ribiti ti o tobi gidigidi a ko le ri ara rẹ tan nitori o ti tobi ju, a ri ẹwọn nla kan ti o so nkan nã rọ soke a si ri ẹnikan ti o wà lok patapata ti o nbu epo si ẹwọn nã. Nigbati a wo o ta o bi wa bi a ba mọ nkan ti a ri a si wi fun u pe a k mọ ọ. O dahun o ni : ' Aiye ni ẹnyin ri i nì, Ẹlẹda so o rọ si agbedemeji ni, ẹniti ẹ ri ti o nbu epo si ẹwọn nì jẹ ọkan ninu awọn iranṣẹ Olodumare ti o ntọju aiye o nbu epo si ẹwọn nã ki aiye má ba ja lulẹ ki o má b fọ. Oju lasan ko le ri ẹwọn ti ẹnyin ri yi, digi yi n l'o le ri i.'

" Nigbati a tun wo o titi, a jade kuro ni iyãra n o si mu wa bọ si agbala rẹ nibiti a ti ri onirũru igi keker gbogbo ti ewe wọn tutu ti o dudu mirinmirin ti nwọn





ni itannã ti o lẹwa pupọ ti o si jẹ onirũru, ati oriṣiriṣi àwọ. Nigbati a de ibẹ o ni ki a duro, o si bẹrẹsi ọrọ isọ o ni, ' Awọn eweko ti ẹ ri wọnyi wà bi apẹrẹ ati mã ran mi leti bi Ẹlẹda ti ṣe nkan inu aiye, wipe aiye kò dọgba. Ẹ wo igi ti o lẹwà ninu gbogbo wọn julọ yi, ewe rẹ, majèlé ni ; bi ẹranko jẹ ẹ kiku ni yio ku, bi enia jẹ ẹ kiku ni yio ku. Eyi ekeji ti ó duro tì yi, ti ko ni itanna rara ti o si ni ẹgun lara, ewe daradara ni ; ko si aisan ti kò le wò ni ode aiye yi, o le wo ètẹ̀, o le wo ṣọpọnna, o le wo warapa, o si le wo sobiya, on ni nwọn fi nṣe àgbo imarale ; ẹ wo igi ti o wa ni eti ọgba yi ti ko ni eso kan lori, igi ìyè ni ; emi ni mo mu u lati ode ọrun wa ti mo wa gbin i si àgbàlá mi. Mo bẹ Ẹlẹda mi lọpọlọpọ ki o to jẹki nmu u wa, ẽkan-ṣoṣo ni o so lati igbati o ti de ihin, mo si ka eso nã jẹ, nipa bẽ mo di ẹni aiku. Nitori ẹniti o ba ti jẹ ẹ ohun kan ti o kù fun u lati ṣe ni pe ki o lọ si ile ẹniti a npe ni Ògódògo ki o gbe ẹwu aiku wọ nitori ibẹ ni onirũru da ti o ba ṣẹṣẹ ti ọrun wa ti mã nwọ ẹwu wọn nitori ọpọlọpọ ẹwu ni mbẹ ninu ile Ogodogo, ti iku mbẹ ti aiku si mbẹ.

" ' Ẹnyin ọmọ enia, bakannã ni ẹ jẹ onirũru ni ode aiye, Ẹlẹda ko pin ẹbun ti O fun olukuluku dọgba. Ẹlomiran wà o ni ẹbun ọrọ sisọ, bi o ba sọrọ bi ẹnipe ki nwọn mã pọn ẹnu rẹ la ni ; ẹlomiran wà ti kò le ọrọ pupọ ṣugbọn ti o le ronu ju ẹlomiran lọ ; ẹlomiran jẹ arẹwa ti o nwu gbogbo ẹda alãye ; omiran jẹ oburẹwa ti ko fa ẹnikẹni mọra ; ẹlomiran ga fiofio ; omiran kuru o dabi kùkùté ; omiran si mọ ni iwọntunwọnsi, bi o ti wu Ẹlẹda ni O pin ẹbun Rẹ lãrin awọn ọmọ araiye.

" Nigbati ọkunrin nã pari ọrọ rẹ tan o wi fun wa ki a wọle ki on mu wa wọ iyãra ti a o mã gbe titi a o

fi lọ. Ọtọ̃tọ ni iyãra ti o fi fun emi ati Ero-ẹhin, iyãra ti Ero-ẹhin kọju si temi. Ninu iyãra mi mo ri aga meji ti nwọn fi fadaka ṣe mo si ri ibusun gõlu kan ti nwọn gbe timutimu titobi le lori. Mo ri awọn ẹiyẹ meje ti o lẹwa tobẹ̃ ti nko ri ẹiyẹ ti o dara tobẹ̃ ri. Bi mo ti wọle ti mo joko ṣe ni awọn ẹiyẹ nã bẹrẹ orin, ohun wọn si dun tobẹ̃ ti o jẹ pe nko mọ igbati mo fi ẹhin le ilẹ ti mo sunlọ. Ilẹ si nṣu lọ pẹlu.

"Nigbati mo mã ji lãrin oru ṣe ni mo ba ẹwu nla ãrán pupa kan lọrun mi, mo si ba ṣokoto titobi kan bayi ni idi mi pẹlu, mo ri awọn kan nwọn njo yi ibusun mi po, nwọn ni ori enia ṣugbọn ẹsẹ malũ ni ẹsẹ wọn. Nigbati o pẹ diẹ ti nwọn ti nyi mi po nwọn bẹrẹsi patẹwọ le mi lori. Igbati o ṣe, nwọn gbe emi ati ibusun mi lọ si oke, nigbati mo de oke mo ri i pe nwọn tun ti gbe ibusun Ero-ọkan bẹ̃ nwọn si gbe e sunmọ temi, njẹ bi a ti ni ki a mã sọrọ si ara wa nwọn tun gbe ibusun wa pada si iyãra wa. Bayi ni nwọn si bẹrẹsi gbe wa soke ti nwọn ngbe wa sọkalẹ titi agogo kan bayi fi lu ti nwọn tuka. Nigbati nwọn lọ tan nko ri ẹwu agbádá nla ti mo ba l'ọrun mi loju orun mọ, nko ri fila rẹ bẹ̃ni nko ri ṣokoto pẹlu.

"Mo yọju si ode mo si ri i pe ilẹ nmọ lọ mo dide mo lọ ba Ero-ọkan ni iyãra rẹ a si jọ pa ero bi a o ti ṣe lọ sọ fun Itanforiti nigbati ilẹ ba mọ.

"Nigbati ilẹ mọ a lọ sọ fun u ṣugbọn esi ti o fun wa ni yi, o ni: 'Awọn ti ẹ ri wọnni, ọmọ mi ni gbogbo wọn, nwọn wa ṣe yin ni alejo ni.'

"Lọjọ keji a ko ṣe nkankan, a nṣire ka inu ile nã titi ilẹ fi ṣu ni. Ṣugbọn nigbati o di alẹ nwọn gbe onjẹ ti o dara fun wa, iyan ni nwọn gun pẹlu ọbẹ ata ti o kun fun ọpọlọpọ ẹran. Ṣugbọn bi a tun ti jẹun ninu iyãra wa tan ni mo tun ri awọn ẹiyẹ meje ti o fo wa si





iyãra mi, bi nwọn ti de ni nwọn bẹrẹsi kọrin, bi nwọn ti nkọrin ni orun tun nkùn mi, mo si ṣe bẹ̃ mo sunlọ.

"Nigbati o di oru ti mo ji mo ba ọpọlọpọ atupa kekeke ni iyãra mi ṣugbọn nko ri ẹnikan. Bi mo ti dide ni mo ri ọwọ kan ti o ko ọwọ mi mejeji si ẹhin ti o fun u ni okun danindanin, bẹ̃ni nko ri ẹniti o ni ọwọ nã. Igbati o ṣe mi bẹ̃ tan o fa okun ọwọ mi o nfa mi kiri iyãra nã. Nigbati o tun ṣe mo ri i o tu okun ọwọ mi, mo si ri ọwọ kan ti o gbe ẹsẹ mi, mo ri ikeji o gbe mi lori, nwọn si sọ mi si apakan iyãra mi, igbati mo si mã de ibẹ ọwọ miran ni mo bọ si, nko kuku mọ ẹniti o gbe mi, bẹ̃ ni nwọn si nju mi si ara wọn. Nigbati o ṣe mo ngbọ gìrìgìrì ẹsẹ ni iyãra mi mo si ri ọpọlọpọ ọwọ ti o gbe mi ti o da ori mi kọ odo ti o ko mi l'ẹsẹ soke. Bi mo si ti nwọ oke mo ri ọwọ nã o tun gbe Ero-ọkan wa, o fi ẹsẹ rẹ le ẹsẹ mi ti mo kọ si oke, ori on si nkan oke aja. Mo gbiyanju ki nkigbe ṣugbọn ahọn mi ko le yipada. Nwọn si bẹrẹsi ṣe nkan gbogbo si wa bayi loru yi titi akukọ fi kọ. Bi akukọ ti kọ tan a ba ara wa lori ibusun wa.

"Nigbati ilẹ mọ a lọ si ọdọ Itanforiti a tun sọ fun u ohun gbogbo ti oju wa ri loru. Inu on pãpã kò dun si i, o dahun o ni:

"'Ẹ maṣe binu, ẹnyin ọmọ enia, onirũru awọn ẹda l'o foriti mi, ẹda lile, ẹda ìkà, ẹda buruku gbogbo, ṣugbọn bakannã ni eyiti o nilãri wà ni ile. Ẹ maṣe binu ohun ti nwọn ṣe ng o kilọ fun wọn.'

"Bi a ti jẹun owurọ tan ni Itanforiti ke si wa ti o mu wa lọ si ibi titobi kan bayi ninu ile rẹ. Aga nla kan wà ni apa oke bayi, lori eleyi l'o joko le o si wi fun wa ki a joko le aga ti o wà ni isalẹ ti o si sunmọ tirẹ diẹ bayi, ki a kọju si on a si ṣe bẹ̃.

## ITANFORITI ATI ONIRURU IWA ỌMỌ ENIA.

"Nigbati a joko tan o bẹrẹsi ọrọ isọ o ni, 'Ọba ilu Alupayida ran yin wa si ọdọ mi lati kọ ọgbọn. Ẹ fetisilẹ ki a sọrọ lori awọn iwa ọmọ araiye gbogbo ti ko njẹki nwọn le lọ siwaju ninu nkan wọn.

"'Ẹ jẹki a sọrọ lori ojukokoro. Kini ojukokoro? Itumọ rẹ ni, oju ko kuro ni nkan oninkan—ile onile, aṣọ alaṣọ, owo olowo, onjẹ olonjẹ, ati awọn nkan bẹ̃ lọ. Ẹṣẹ nã dabi kokoro ti njẹ awọn ọmọ araiye ni gbongbo, ti ko jẹki nwọn lọ siwaju bi nwọn iba ti lọ. Bi enia ba ti bẹrẹ ojukokoro ṣe ni yio mã hu iwa nã si onirũru nkan, nkan oluwarẹ ko ni tẹ ẹ lọrun mọ ko si le ni igbadun kan lori wọn. Awọn olojukokoro ni nwọn mã nba orukọ olorukọ jẹ, nitori igbati nwọn ko le ri aye de ibiti onitọhun de nwọn a bẹrẹ ègàn pipa.

"'Ṣugbọn ibanujẹ olojukokoro buru ju ti ẹniti ọfọ ṣẹ̀ nitori ko le tan, bi o ba ti ri nkan ẹlomiran ni yio mã wù u, bẹ̃ni ẹlomiran ko le ṣe alaini nkan on ko si ni le ni i. Ojukokoro ko mọ pe enia tobi, ati ẹniti o tobi ati ẹniti kò tobi ni o le ni i. Ọba ilu le ni i si awọn ọmọ abẹ rẹ̀, awọn ọmọ ilu si le ni i si olori wọn, ọmọde a mã fi oju bọ nkan àgbà, àgbà a si mã fi oju bọ nkan ọmọde, ko si ẹniti o le bọ ninu ẹṣẹ nã afi ẹniti o ba ko ara rẹ̀ ni ìjánu.

"'Kini ibẹrẹ ole? Ojukokoro ni ibẹrẹ ole on l'o si nda awọn ọlọṣa lãmu kiri. Ati kekere l'o ti yẹ ki a gba ojukokoro lọwọ ọmọde, kò yẹ ki ọmọde ni iwa ati mã tọrọ nkan jẹ lọwọ ẹlomiran tabi ki a mã jẹun ki ọmọde joko ki o mã wo ẹniti njẹun bi ẹnipe ki o fun on jẹ. Ojõjumọ ni awọn ọmọ miran mã nbẽre owo





lọwọ obi wọn nwọn a mã ra ọpọlọpọ nkan ti ẹgbẹ wọn rà, nkan ti nwọn ba ti ri lọwọ ẹnikeji nwọn a fẹ ni i. Lõtọ ko yẹ ki oju ti ọmọde lãrin ẹgbẹ ṣugbọn iwọntun-wọnsi ni ohun gbogbo. O yẹ ki awọn obi di ara wọn ni amure ki nwọn ba ẹṣẹ buruku iru eyi ja, ki nwọn gba awọn ọmọ wọn lọwọ ibajẹ, nitori ẹniti o ba ti bẹrẹ ojukokoro ni kutukutu ọjọ aiye rẹ̀ ti fi ipilẹ aiye rẹ̀ sọ ilẹ lori àbàtà eti odò, aiye nã ko si le duro. Awọn iru ọmọ bayi ni nwọn ndagba ti nwọn ndi ọkunrin ti o nfẹ ogunlọgọ obinrin jọ ati obinrin ti ngba nkan lọwọ ọkunrin ọlọkunrin kiri. Igbesi aiye awọn wọnni ko yẹ bi apẹ̃rẹ fun iran ti nbọ lẹhin. Ẹniti o ba ti gbe ojukokoro wọ̀ bi ẹwu oluwarẹ ti wọ ẹwọn eṣu, bẹ̃ni ẹniti o ba wọ ẹwọn eṣu ti kuro ni ọmọ enia, o ti di ẹni lasan inu aiye.

"'Ojukokoro mã nran bi õrun buruku ni, bi o ba si ti bẹrẹ ki iṣe imu kuro bọ̀rọ̀.

"'Ẹ jẹki nsọ itan kan fun yin ki ẹ ba mọ bi iwa nã ti buru to.

"'Kọlọkọlọ ati igbin jọ jẹ ọrẹ nwọn si ni takute kan, nwọn pinnu ati mã dẹ takute yi de awọn ẹranko.

"'Lọjọ ti nwọn kọ dẹ ẹ, takute mu ekute kan. Nigbati awọn mejẽji de ibẹ igbin wi bayi fun kọlọkọlọ, o ni, "Takute wa pa ekute lọni, ọrẹ mi, mu eleyi, nigbati o ba di ọla, yio pa okete, okete si tobi ju ekute lọ, ng o mu eleyini lọla".

"'Nigbati kọlọkọlọ gbọ bayi o dahun o ni, "Ng o kuku rọju duro di ọla, ọrẹ mi, mã gbe eyi lọ".

"'Igbin gbe ekute nã lọ. Lõtọ takute pa okete lọjọ keji. Nigbati awọn mejẽji de ibẹ ti igbin wo o, o ni, "Mo ba ọ yọ, ọrẹ mi, okete yi mà kuku tobi o, ṣugbọn ko le tobi to idamẹrin ọ̀yà mi ti takute o pa lọla".

"'Nigbati kọlọkọlọ tun gbọ, inu rẹ̀ bajẹ, o duro diẹ,

nigbati o ṣe, o sọrọ o ni, " Lõtọ ọ̀yà tobi pupọ, kuku mã gbe okete lọ loni, igbin, jẹki ngbe ọya lọla ".

" ' Igbin ṣe bẹ̃ o gbe okete lọ. Nigbati o di ọjọ keji lẹhin eyi, nwọn tun lọ wo takute o si ti mu ọ̀yà nitotọ. Nigbati igbin ri i o ke si kọlọkọlọ o ni : " Kọlọkọlọ, yara mã bọ, takute ti mu ọ̀yà, ọ̀yà nã tobi, ọ̀dù ọ̀yà ni. Mã gbe nkan rẹ lọ, o di ọla ki emi to gbe akata, akata ẹran ọlọra, o tobi ju ọya lọ dãdã ".

" ' Nigbati kọlọkọlọ tun gbọ eyi o bẹrẹsi ronu, nigbati o ṣe, o ni, " Mã gbe ọ̀yà lọ, ẹran ọlọra ni akata, ng o gbe e ki iyawo mi ri nkan se ọbẹ̀ lọla ".

" ' Nigbati ilẹ ọjọ keji tun mọ nwọn lọ si idi takute, nigbati nwọn de ọhun o ti pa akata lõtọ, nigbati igbin tun ri i o sọrọ o ni : " Mo ba ọ yọ, kọlọkọlọ, ẹ wò bi akata nã ti tobi to, ori rẹ ṣe nkan fun ọ, mã gbe e, ko buru, ọla ni ọwọ mi o ba agbọnrin, agbalagba ẹranko ti on ti iwo lori ṣaraṣara ".

" ' Ẹnyin ọrẹ mi, alakọri ni kọlọkọlọ, nigbati o gbọ bayi o dorikodo o ni, " Ki agbọnrin tun bọ si ọwọ igbin ! Ẹran ara agbọnrin fẹrẹ ju gbogbo ẹran ti a ti npa lọ. Igbin o, mã gbe akata lọ, ng o gbe agbọnrin lọla ".

" ' Igbin tun ṣe bẹ̃ o gbe akata lọ, nigbati o tun di ọjọ keji, takute pa agbọnrin. Nigbati nwọn de ibẹ igbin kigbe o ni, " A ! Ọwọ ba agbọnrin ẹranko ti o ni ara pupa ati ara funfun, ẹranko a bi iwo lori ṣaraṣara, kọlọkọlọ, mã gbe nkan rẹ, ṣugbọn ng o ṣe ariya pataki kan lọla ng o si pe ọ wa si ile mi, nitori ọla ni ọjọ ti takute mã pa ẹfọn, bẹ̃ni ẹfọn tobi ju gbogbo awọn ẹranko kekeke wọnyi lọ ".

" ' Nigbati o wi bayi, inu kọlọkọlọ tun bajẹ, o rin diẹ, o duro, o tun rin o duro, nigbati o ṣe ko le lọ mọ o tun sọrọ o ni : " Igbin, o kù ki nmu sũru diẹ si i,





kuku jẹki ngbe ẹfọn lọla, mã gbe agbọnrin lọ." Igbin tun gbe agbọnrin lọ.

" ' Nigbati o di ọjọ keji, takute pa ẹfọn, igbin l'o si kọ de ibẹ ti o ri i. Were o ke si kọlọkọlọ, igbati kọlọkọlọ de ọhun o dahun o ni : " Ọrẹ mi, mo ba ọ yọ, o ku orĩre, ọwọ rẹ ba igba keji erin, ni gbogbo ẹranko inu igbo ko si eyiti o tobi to erin, ọla ni ọjọ ti ọwọ mi o ba a, nitori takute yio pa erin lọla. Mã gbe eyi lọ ".

" ' Ọrọ yi mu ki ọkan kọlọkọlọ gba ọgbẹ nitori erin ni o tobi ju gbogbo awọn ẹranko lọ. O duro titi o si tun wi fun igbin ni igbẹhin pe ki o mã gbe ẹfọ̀n lọ.

" ' Takute pa erin lọjọ keji. Nigbati nwọn de ibẹ kọlọkọlọ ti mura kankan, ṣugbọn nigbati igbin wo o titi o ni : " O jẹ ye yọ ara rẹ lẹnu, ọla ni yio kuku pa Ọràn, Ọràn si tobi ju erin ni igba mẹwa lọ. Nigbati kọlọkọlọ gbọ bayi ti o si ri i pe õtọ ni·gbogbo asọtẹlẹ ti igbin ti nsọ nbọ si o fi erin silẹ fun igbin, o ni on o duro de Ọràn lọjọ keji ".

" ' Igbati igbin gbe erin rẹ̀ lọ tan o tun pada wa si ibi takute lọjọ nã o yi i pada si ọna ti ọmọ ọba mã nba rin lojojumọ.

" ' Igbati ilẹ ọjọ keji mọ ti ọmọ ọba fẹ jade, takute mu u, gbogbo enia si bẹrẹsi ke pe " Tani da Ọran yi o ? " Bi nwọn ti ke bayi, kọlọkọlọ jade, o ni, " Ọran nã da ? Ọran nã dà ? Temi ni, temi ni." Bi o ti wi bayi nwọn mu u, nigbati o si de ibiti takute wà o ri i pe ọmọ ọba ni takute mu. Were o yi ohun pada o ni ki iṣe on ni on pa ọmọ ọba, wipe igbin ni. Nigbati o pẹ ṣa ti ẹnu rẹ̀ le dãdã nwọn mu igbin nwọn da a lẹbi iku. Nigbati o di ọjọ iku igbin, igbin wọ aṣọ titobi ti o si lẹwa gidigidi, o gun ẹṣin kan o si ko awọn ti nlu ilu o ni ki nwọn mã lu u tẹle on, o ni ki nwọn mã fi ilu wi bayi pe, " Ẹni ba pa ọmọ ọba l'ọba nfun lẹṣin, igbin pa ọmọ

ọba, ọba fun u l'ẹṣin, ọba fun u l'ẹṣin, ọba fun u l'ẹṣin, igbin pa ọmọ ọba, ọba fun u l'ẹṣin." Bayi ni igbin ni ki nwọn mã lu ilu tẹle on, o mura o gun ẹṣin lọ si ẹhinkunle kọlọkọlọ, nigbati nwọn de ọhun o ni ki nwọn tẹ gọ̀ngọ́ mọ ilu wọn nwọn si tẹ ẹ mọ ọ. Kini kọlọkọlọ gbọ bayi ṣe, were o sa jade o ni," Mo tilẹ fẹ jẹwọ na, mo fẹ jẹwọ emi ni mo pa ọmọ ọba, emi ni mo nilati gun ẹṣin." O lọ si ile ọba lẹsẹkannã, o de ọhun o ni on ni on pa ọmọ ọba. Were nwọn mu u nwọn si pa a bi aṣẹ ọba.

" 'Ibẹ ni kọlọkọlọ pari aiye tirẹ̀ si. O ku nitori oju rẹ̀ ko le kuro ni nkan oninkan, o fẹ ki ohun gbogbo jẹ ti on, ko fẹ ki ẹlomiran ni nkan ti on kò ni, o lepa titi o sọ ẹmi ara rẹ̀ nù si ibiti o ti nlepa. Bayi ni aiye ri ẹnyin ọrẹ mi, ẹlomiran fẹ ki ile on jẹ ile iṣura bi ile ọba ko si ni gba ọna tãra bi oju omi, a mã wa ohun olohun mọra, tirẹ̀ ko ni ni iyi loju rẹ̀ mọ ṣugbọn ti ẹni ẹlẹni a wọ ọ loju ṣọṣọ, nkan bayi ni ki ẹ tẹ mọ ọba ilu yin leti, ki o mã le ojukokoro lati ile de ile, ki o mã gba a lọwọ awọn ọmọ ilu, ki o ṣe ofin ti yio le ojukokoro jina réré. Ojukokoro ko yẹ ilu, o dabi ẹgun pẹlu atẹlẹsẹ ti kò njẹki ẹlẹsẹ sare. Ilu ti o ba gbe ojukokoro si aiya ko le lọ siwaju bi o ti wù ki o ṣe to.

" 'Ẹ jẹki a tun sọrọ lori nkan miran, ẹ jẹki a sọrọ lori igberaga. Kini igberaga ? Igberaga ni ki a gbe ara ẹni ka ibiti a kò to de, yala ki a ro o lọkan ẹni, ki a sọ ọ jade lẹnu, tabi ki a hu u ni iwa. Igberaga a mã sọ ni di ero ẹhin, a mã gbe ni ṣubu, ko si si nkan ti o ngbe ẹ̀wù ẹ̀tẹ́ bọ ni lọrun bi igberaga. Oju kekere ni awọn enia fi mã nwo onigberaga.

" 'Ibi nkan kekere ni igberaga ti mã nfi ara han. Ẹ jẹki a wo nipa ki a mã ki enia yi, ọpọlọpọ ọmọde ko nki awọn agbalagba pẹlu ọ̀wọ̀ mọ ni aiye isisiyi, bi



ITANFORITI ATI ONIRURU IWA ỌMỌ ENIA

nwọn ba wipe ki awọn ki agbalagba bi aṣa ọmọwe awọn ni yio kọ yọ ọwọ wọn jade ti nwọn o na a si agba wọn. Ko si tilẹ si pe ki nwọn ki ẹniti o ju wọn lọ bi aṣa ibilẹ ki nwọn dọbalẹ rara, awọn kọ, awọn ọmọ iwoyi ko si nyẹ awọn obi wọn si bi o ti yẹ, bi nwọn ran wọn ni iṣẹ ati dide a di nkan, ki nwọn si to ṣiṣẹ nã tan ọjọ a ti lọ, iwa ẽri ni eyi, iwa ti ki ijẹki ọmọde lọ siwaju ni. Awọn ọdọmọbinrin yẹ ki nwọn ki ara wọn ni ìlọ̀ nigbati nwọn ba bẹrẹsi dagba, ọpọlọpọ ro o si iwa afinju lati mã sọrọ bi nwọn ba ti fẹ si iya wọn. Nwọn a lọ si ode bi nwọn ba ti fẹ, nwọn a pada nigbati o ba wù wọn bi o ba si bi wọn ni eyi nwọn a ni awọn ni awọn ni ara awọn.

" 'Kini gbese ti ṣe mã npọ lode aiye ? Ara igberaga nã ni. Ki enia ṣe aini ipa ati ra nkan ki o ra a, ki o jẹ talaka ki o wọ ẹgbẹ awọn olowo, ki o ni pọnun kan ki o fi ipilẹ ile sọ ilẹ, ki o ti ipa bẹ̃ da gbese rẹ́kẹrẹ̀kẹ, ẹniti o ba nṣe ohun ti ko to ṣe afi bi ẹniti o fun ara rẹ̀ ni májẹ̀lé ni. O yẹ ki ọmọluwabi mã ro nkan ki o to ṣe e, pupọ ninu awọn obinrin fẹran aṣehan nitorinã nwọn kò nlè ki ara wọn ni ìlọ̀ ati ra aṣọ, ogunlọgọ a si mã wọ aṣọ ẹgbẹjọda pẹlu ẹru gbese lọrun wọn. Igbati nwọn ba jade ninu ẹgbẹ ironu ko ni jẹki nwọn simi, nwọn dabi ọmọ igba ti ko ri idi joko nwọn a mã ti ori kòtò bọ si ori gegele.

" 'Bi enia ba tilẹ jẹ ẹniti o wà ni ipo nla o yẹ ki o mọ bi on o ti ṣe lo ipo on. Ọpọlọpọ awọn olori ni nwọn ti di ero ẹhin nipa igberaga. Ero wọn ninu ara wọn ni eyi pe ọwọ awọn ti tẹ ẽku ida awọn si le lo ida nã bi o ba ti wu awọn. Ede yi ni awọn ọmọ abẹ wọn mọ dãdã on l'o si nmu ki nwọn mã fi imẹlẹ ṣiṣẹ eyiti ki imu ki iṣẹ lọ siwaju, a si mã re ẹhin titi olori a fi di enia yẹpẹrẹ. O yẹ pupọ pe ki awọn ti o ba wà ni ipo

olori mọ ododo ọrọ nã ti o lọ bayi wipe, ṣe ni ipo mã ngun ni bi oriṣa, a mã pa ni bi ẹmu, eyi a mu ki oluwarẹ yi iwa pada ki o kuro ni ipo ọmọluwabi ki o mã lo ipo bi o ba ti wu u ati ni ọna ti ko yẹ.

“ ‘ Ẹnyin ọmọ enia, njẹ ẹnyin ri i ki Olodumare binu lọjọ kan pe on ko ran õrun mọ tabi ki O wipe oṣupa ko ni iyọ ? Bẽni ọwọ Olodumare ni agbara wa kò si jẹ sọ wipe nitori pe o wà lọwọ On ki On lo o ni ọna ti kò yẹ. O yẹ ki awọn ti o ba wà ni ipo aṣãju mọ ipo wọn ni ipo ẹlẹgẹ, ki awọn olori ẹgbẹ mã wa ọna ati tun ẹgbẹ ṣe nipa iwa wọn, ki awọn ọmọ alade ati awọn alagbara gbogbo mọ pe bi o ti wù ti awọn tobi to sibẹ awọn wà labẹ Olodumare. Ẹniti o ba ngbe ara rẹ ga ti fi aṣọ irẹsilẹ bora.

“ ‘ Ọpọlọpọ enia a mã sọ anfani nù nipa igberaga wọn, ogunlọgọ wunndia l’o ti sọ ọkọ anfani nù nipa igberaga, ẹlomiran a wo enia bi ẹnipe Ọlọrun kọ ni o da oluwarẹ̀, a fi oju kekere wo o, a wo o de ilẹ ko, omiran a pade enia ko ni ki i, bi nwọn tun ki i kò ni dahun. Ẹniti o nwọ mọto ayọkẹlẹ kiri ni nwọn nwa kiri, asẹhinwa asẹhinbọ nwọn ko ni ri ọkọ ti o ni mọto fẹ, ibiti nwọn si ti kọ silẹ ko ni ṣẽ pada si mọ, nwọn a bẹ igi di oju ọna aiye ara wọn.

“ ‘ Bakannã si ni awọn ọkunrin, awọn ẹlomiran nwa ọmọ ọlọla kiri, igbati nwọn ba fẹ eyini pãpã, ti o wà ni ode, ko ni fẹran wọn, bi agbara ni nwọn a fi so ara mọ ọ, asẹhinwa asẹhinbọ ọmọ ọlọla a wọle, ọjọ ti o ba si ti wọle ni anfani ti salọ ni ile wọn, ija, èpè, ẽbu ko ni jẹki enia gbọran mọ, nwọn a mã ja gidigbo ninu ile, nwọn a mã ro ẹjọ ara wọn kãkiri ode, nwọn a si mã fi paṣan le ara wọn kiri bi o ba wù wọn.

“ ‘ Awọn onigberaga kò ṣẽ ba joko ni awujọ, nwọn ko kuku ni fi ara wọn si ipo irẹlẹ, ibi giga ni nwọn a





mã wa kiri, igbati ọrọ ba kanlẹ nwọn a sọ ju gbogbo enia lọ, nwọn a sọ eyiti o tọ, nwọn a sọ eyiti kò tọ, nwọn a si mã wa ọpọlọpọ ọna lati fihan araiye pe awọn mọ gbogbo nkan. Onigberaga ni olori alaimọkan, ibaṣepe onigberaga mọ nkan ni iba mọ pe iwa on ni yio wo on lulẹ bi igi, ti on o di ero ẹhin ati ẹni iwọsi, ti awọn araiye yio mã sọrọ on ni buruku lẹhin ti orukọ on ba yipada kuro ni ipo ọmọluwabi si alaimọkan. Awọn ẹniti o ba nfọnnu dabi igi ti ko ni gbongbo ti ko si le duro pẹ nitori nwọn ko mọ bi awọn ti ri, nwọn ko mọ bi awọn ti kere to, ero inu wọn ni pe awọn jẹ ẹni nla bẽni nwọn ko ju kekere lọ, ati lọ siwaju wọn kò le ṣai jẹ iṣoro. Igberaga ni iṣãju iparun, on ni nfi aṣọ itiju bo ni lara, on ni ki ijẹki enia gbẹkẹle ọrọ ẹnu ẹni. Iwa yi jẹ abawọn ti o buru pupọ, mo si fẹ ki ẹ sọ fun ọba ilu Alupayida pe ki o wa ọnakọna ti o le ri ki o mu ìwà nã kuro ni ilu rẹ.

“ ‘ Nkan miran tun ṣe pataki pupọ ti o yẹ ki a tun sọrọ le lori, ifẹ. Ifẹ jẹ nkan ti o ṣe pataki pupọ ni ode aiye, on ni enia fi le ko ọmọnikeji rẹ ni ìjánu. Ko si olori ti ko ba ni ifẹ ti iṣẹ rẹ le yọ. Ifẹ ijinlẹ kan wà ti o lagbara ti o si mã nfi han ni ohun ti ifẹ pipe jẹ, eyi ni ifẹ gbigbona iru eyiti o mã nwà lãrin ọkunrin ati afẹsọna iyawo rẹ. Iru ifẹ yi ni o fi ohun ti ifẹ le ṣe han ni, bi o ti jẹ pe o le mu ki enia fi ara da iṣoro to bi o ba mbẹ ninu ọkan ẹni, ti o le ru bo ni loju bi ẹmu ti o si fi yẹ pe o yẹ ki enia mã da ironu pọ mọ ifẹ rẹ ki oluwarẹ̀ má ba dabi aṣiwere nibiti ifẹ ti ntì i kiri.

“ ‘ Ṣugbọn mo fẹ fi ifẹ obinrin kan ti mo gbọ itan rẹ han yin, ifẹ pipe ni. Bayi ni itan nã lọ :

“ ‘ Ọba kan wà ti o lowo, ti o lọla, ti o lokiki, ti o si lagbara. Lọjọ kan, ọmọ rẹ akọbi ti o jẹ arẹmọ rẹ

nṣe ọjọ ìbí, onirũru enia si bẹrẹsi fun ọba yi ni ẹbun nitori ọjọ ìbí ọmọ rẹ̀.

"'Ọkunrin kan wa mu ẹṣin kan wa fun u, igi ni nwọn fi ṣe ẹṣin yi, nwọn gbẹ ẹ ni ere ni. Nigbati ọkunrin yi mu ẹṣin nã de o wi fun ọba pe bi enia ba gun u ti o yi igi pẹlẹbẹ kan ti mbẹ ni ibi eti rẹ̀ ẹṣin nã yio fò yio si gbe oluwarẹ lọ si ofũrufu ni. Eleyi ya ọba lẹnu o si wi fun ọkunrin nã bayi o ni: "Bi ó ba ṣe õtọ ni ọrọ rẹ, gun ẹṣin nã lofũrufu ki nri ọ ki o si lọ ja ewe ti mbẹ lọhun nì fun mi."

"'Bi ọba ti wi bayi ni ọkunrin nã ti ta le ẹṣin yi, were ti o yi igi kekere eti ẹṣin àràmọ̀dà yi ẹṣin gbe e soke, o fò lọ, o si ja ewe igi ti ọba wi fun u.

"'Iyalẹnu ni eyi jẹ fun gbogbo enia, ọmọ ọba ti nṣe ọjọ ìbí si wi fun ẹlẹṣin pe on nã fẹ dan ẹṣin nã wò. Were o bọ le ori ẹṣin were o yi igi kekere eti ẹṣin bẽni ko tilẹ gba imọran lọwọ ẹlẹṣin titi o fi yi i. Bi o ti ṣe bayi ẹṣin fo si ofũrufu o ngbe e lọ. Nigbati o fẹ ki ẹṣin pada o yi igi si ọna miran ẹṣin kò pada, o fẹ ki ẹṣin gbe on lọ si ilẹ o bẹrẹsi yi igi yi ṣugbọn ẹṣin nlọ ṣa ni.

"'Ọba binu pẹlu ẹlẹṣin nitori ẹṣin gbe ọmọ rẹ̀ lọ o si paṣẹ ki nwọn ju u si ẹ̀wọ̀n werewere, bi ọmọ on ba bọ on o yọ ọ kuro bi ko ba si pada on o pa a.

"'Bayi ni ẹṣin gbe ọmọ ọba yi lọ ti o ku on nikan lori ẹṣin lofũrufu, ẹṣin nsare lọ on nã nronu ohun ti o de ba on, ẹṣin sare titi ilẹ fi ṣu. Nigbati o pẹ diẹ ti ilẹ ti ṣu ti oṣupa ti yọ ni ọmọ ọba yi wa wo apa keji ẹṣin nã wò ti o tun ri igi kekere kan, o ba yi igi yi wò, af igbati ẹṣin ngbe e lọ si ilẹ.

"'Pẹlu ijaiya nã l'o fi nlọ nitori ko mọ ibiti on mã balẹ si ṣugbọn nigbati o ṣe o de ilẹ ọkan rẹ̀ si balẹ diẹ ṣugbọn ko mọ ibiti on de, bi o si ti nwo ayika rẹ̀ kiri





o ri ina kan ni ọ̀kánkán o si lọ si ibẹ. Nigbati o de ibẹ, o ba ãfin titobi kan, o wọle.

"'Bi o ti wọle o ri ọpọlọpọ awọn obinrin ti o sun silẹ lọ o si ri ọkan ninu wọn ti o sun si ori ibusun ti o dara ju gbogbo ibusun ibẹ lọ, obinrin nã ko da aṣọ bori, o fi oju si ita. Nigbati ọmọ ọba yi ri i ẹwa rẹ̀ ya a lẹnu, o rọra yọ kẹlẹkẹlẹ o lọ si ibi ibusun nã o duro o nwo o. Ko pẹ ti o duro bayi ni obinrin nã la oju ti o wo o, bi o ti ri i o dahun o ni: "Tani ọ, nibo l'o si ti wa?" Ọmọ ọba nã si da a lohun bayi, o ni: "Bi mo ti ri ọ yi mo mọ pe ọmọ ọba kan ni ọ, anfani ọmọ ọba mbẹ lara rẹ, emi ti mo si duro yi pẹlu, ọmọ ọba ni emi nã, ṣugbọn ki nto sọ itan ara mi, mo bẹ ọ tọkantọkan ki o ba mi wa onjẹ diẹ ki njẹ nitori ebi npa mi gidigidi."

"'Bayi ni ọmọ ọba yi wi, obinrin nã si dide o ji awọn ọmọ ile nã o ni ki nwọn gbe ọbẹ̀ gbona. Nwọn ṣe bi o ti wi werewere o si fun ọmọ ọba yi ni onjẹ. Ọmọ ọba ni obinrin nã nitõtọ, baba rẹ̀ ni o kọ ile nã si ãrin igbo fun u ti o ko awọn iranṣẹ ti i, o jẹ ibiti o wipe ki ọmọ on nã ti mã gbadun afẹ̃fẹ ati pãpã nigbati õru ba mu.

"'Nigbati eyi ọkunrin ti o jẹ ọmọ ọba jẹun tan o bẹrẹsi rohin fun ọmọ ọba obinrin nã bi o ti jẹ pe jẹjẹ on ni on nṣe ọdun ti ẹnikan fi ẹṣin àràmọ̀dà kan ta baba on lọrẹ, ti on gun ori ẹṣin laimọ ọna ati lo o ti o si jẹ pe bẹ̃ ni on ṣe fi ilu on silẹ ti ẹṣin ngbe on kiri, nigbati o darukọ ilu rẹ̀ ti ọmọ ọba obinrin yi si sọ ilu ti o wà fun u, nwọn ri i pe o ti rin to irin ọjọ mẹwa si ilu rẹ̀.

"'Itan yi ya obinrin nã lẹnu o si kãnu ọmọ ọba yi gidigidi, o ni ki awọn ọmọ ọdọ on tọju iyãra kan, ki nwọn gbá ibẹ ki o mọ tonitoni, ki nwọn gbe ibusun ti o nilãri si ibẹ ki nwọn si gbe timutimu ti o tu ni lara

le ori ibusun nã, ki nwọn tun ko timutimu kekeke si ibi ìrọ̀rí ki nwọn ṣe gbogbo ibẹ ki o dara, gbogbo iwọnyi ni nwọn ṣe, ọmọ ọba nã si sun si ibẹ mọju.

" 'Nigbati ilẹ ọjọ keji mọ, obinrin yi ṣe itọju ọmọ ọba nã de gongo, o fun u ni orín o run orín, o mu u lọ si ile ìwẹ̀ o wẹ̀, o wa onjẹ pataki fun u, nigbati ọkunrin nã si mã jẹun, ori tabili kannã ni awọn mejeji joko si, nwọn nṣire nwọn nṣe àwàdà ni ibi onjẹ, nwọn si nrẹrin nwọn npariwo. Nigbati nwọn jẹun tan obinrin nã ni ki ọmọ ọba yi tẹle on ki on mu u yi ile on lọ onitọhun nã si tẹle e, nwọn nti inu iyãra bọ si inu iyãra, nwọn nti iyẹ̀wù de iyẹ̀wù nwọn de ọ̃dẹ̀ nwọn de ẹhinkunle, nwọn ngbadun ara wọn. Ibiti nwọn ti nlọ yi nã ni obinrin yi ti sọ fun ọmọ ọba pe ki o má iti ilọ on nã si gbà si i lẹnu, o ti itori obinrin o gbagbe ile ati wahala ti on fun awọn enia on, ifẹ obinrin sọ ọ di aditi, o di aja ti kò gbọ fere ọdẹ. Obinrin nã ko jẹki ọkunrin yi simi nibiti o ti nṣe fãri han a, aṣọ tan ni ile alaṣọ, bata tan ni ile onibata, ori ọkunrin nã yí pẹlu, awọn mejeji nlọ mọra bi ejo, nwọn ntẹle'ra bi ẽra, nwọn nwọle nwọn njade. Nwọn ko tilẹ ni ero pe ki ọkunrin nã tete pada mọ, nigbati o si pẹ diẹ nwọn fẹ ara wọn.

" 'Nigbati o ṣe nwọn pinnu ati wa lọ si ilu ọmọ ọba ọkunrin yi, nwọn mura ni ijọ kan, nwọn kó diẹ ninu ẹrù obinrin nã le ori ẹṣin aramọda yi awọn mejeji si bọ le ori ẹṣin, ọkunrin joko ni iwaju obinrin wà lẹhin o di ọkunrin ni idi mu. Ọkunrin yi igi kekere eti ẹṣin, ẹṣin fò o di ofũrufu, nwọn kọ ori ẹṣin si ọna ilu ọkunrin nã ko si pẹ to bi nwọn ti ni ero ti nwọn fi yọ si ilu ọmọ ọba nã. Nigbati nwọn de ibẹ nwọn ko lọ si ãfin gãn nitori ọmọ ọba nã ko fẹ ki on ati iyawo on yọ si baba on bẽ, o fẹ kọ lọ sọ fun baba rẹ̀ na ki nwọn wa





fi ilu ati ijo pade iyawo on. Nitorinã ile ti baba rẹ̀ kọ si ẹhin ilu ni nwọn lọ, ibẹ l'o si fi iyawo rẹ̀ si ti o lọ si ãfin.

" 'Nigbati o yọ si ãfin, ariwo ta inu baba rẹ̀ si dun tobẽ ti ko mọ bi on ti ṣe le yọ̀ to, o di mọ ọmọ rẹ̀ o nyẹ ẹ loju wò o nki i. Igbati o ṣè, ti on ati ọmọ rẹ̀ bẹrẹsi sọrọ ni ọmọ rẹ̀ sọ fun u pe on mu iyawo bọ ati wipe o wà ni ile rẹ̀ lẹhin ilu. Inu ọba dun rekọja o si paṣẹ pe ki nwọn yọ ẹniti o ni ẹṣin kuro ni ẹwọn ki o jade ati wipe ko gbọdọ jẹki on ri on mọ.

" 'Ẹlẹṣin yi jade kuro ni ẹwọn lõtọ, o fi ọba ati ọmọ rẹ̀ si ãfin nibiti nwọn gbe nmura ati lọ pade iyawo tuntun ṣugbọn bi o ti nlọ, ile ti iyawo ọmọ ọba nã wà l'o ba lọ. Nigbati o de ọhun, o wi fun awọn ti o wà ninu ile nã pe ọba ni ki on gbe iyawo ọmọ on wa, niwọnigbati nwọn si ti mọ pe on l'o ni ẹṣin nã tẹlẹ ti o si ti wà ni ẹwọn nwọn ko funra pe irọ ni o npa, nwọn fi iyawo ọmọ ọba fun u, o gbe e le ori ẹṣin, o yi igi kekere eti ẹṣin, ẹṣin ba oke lọ, o si mura o gbe iyawo nã ba ọna ãfin lọ. O de ãfin nigbati ọba ati ọmọ rẹ̀ bọ si ita gãn pẹlu ẹwu nla ti nwọn nlọ pade iyawo. Bi o ti yọ si wọn, o ke lati oke o ni, "Oniyẹ̀yẹ́ ku ni ijọ ojo rọ̀, oloriburuku yin nlọ pade iyawo tuntun, mo ti gbe iyawo lọ o."

" 'Nigbati nwọn wo oke ariwo ta, nwọn bẹrẹ èpè, ṣugbọn ṣe l'o fi wọn silẹ ti ẹṣin nsa lọ gbũru. Nigbati iyawo mọ pe o ngbe on lọ kuro ninu ilu ọkọ on ni ṣe l'o bẹrẹsi jà kìtìkìtì, ṣugbọn ko tilẹ wo o loju rara, o ni, " Bi o ko ba ṣọra ṣe l'o mã ja lulẹ ti tapatẹṣẹ rẹ a run womuwomu."

" 'O gbe ọmọ nã lọ o si gbe e rin titi o fi de ibiti o jina to ọjọ mẹwa ni irin ẹsẹ si ilu ọmọ ọba yi, nigbati o de eti ilu kan o sọkalẹ. Nigbati o sọ de ilẹ tan o wi fun obinrin nã pe on o fẹ ẹ ati pe bi ko ba gba lati

fẹ on oju rẹ̀ o ri nkan. Onitọhun kọ̀ jalẹ gbangba on nã si ki ọwọ bọ igbo o ja pașan o ko o bo o, obinrin nã si nkerora.

"'O wa jẹ pe ọba ilu ti nwọn de eti rẹ̀ yi lọ si oko ọdẹ o si npada bọ̀ nigbati obinrin yi nkigbe. O yà si ibiti igbe nã ti nwa o si ba ọkunrin yi nibiti o gbe nna obinrin nã. Eleyi bi ọba nã ninu tobẹ̃ gẹ nigbati o wo ẹwa obinrin nã, ko si șe meji ko șe mẹta șe l'o pașẹ fun awọn ero ẹhin rẹ̀ ki nwọn bẹ ọkunrin nã lori, o pa a o si mu obinrin nã lọ si ãfin tirẹ̀.

"'Ko ju ọsẹ kan ti obinrin yi de ãfin ti ọba ilu yi wipe on o tun fẹ ẹ, nigbati o si rò bi ọba nã ti lagbara to ti o si mọ pe o le pa on bi on ba kọ̀ o gbà lati fẹ ẹ șugbọn gbigbà ti o gbà nã ko ti inu rẹ̀ jade, ẹnu lasan l'o fi wi i o si ti bẹrẹsi ronu ọna ati yọ.

"'Ọba da ọjọ igbeyawo, o fi ile pọn ọti o fi ọna ro ọka șugbọn nigbati o kù diẹ ki ọjọ nã pe obinrin yi yipada o nșe bi așiwere șugbọn ko șiwere rara, o nșe bẹ̃ ni. Ibanujẹ ni eleyi jẹ fun ọba o si bẹrẹsi nawo fun awọn onișegun ki nwọn ba on wo wèrè obinrin on, șugbọn obinrin nã ko tilẹ njẹki nwọn de ọdọ on ni, a mã lù wọn bi nwọn ba ti nbọ, a mã gba wọn leti, nwọn ti ilẹkun mọ on pãpã si iyãra kan ni.

"'Șugbọn kini ọkọ rẹ̀ pãpã ọmọ ọba ti o fi ẹșin gbe ẹ lati ile rẹ̀ wa șe nigbati ẹniti o ni ẹșin gbe iyawo rẹ̀ yi lọ ? Nkan ti o șe ni yi, o yi așọ pada o wọ așọ ẹniti nrin irinajo o pinnu ati wa iyawo rẹ̀ de ibikibi ti o ba le ri i, o fi ori le ọna ibikan șa, o nlọ, ọ nrin lati ilu de ilu, nigbati o șe o de eti ilu ibiti iyawo rẹ̀ yi wà o si gbọ itan nipa rẹ̀ bi ẹnikan ti fi ẹșin àràmọ̀dà kan gbe obinrin kan, ti ọba fẹ fẹ ẹ, ti obinrin nã di așiwere ki ọjọ igbeyawo on ati ọba to pe.

"'O fi eti silẹ o gbọ itan yi kedere o si mọ pe iyawo





on ni, o fi ori le ọna ilu ibiti nwọn wipe o wà. Ko pẹ pupọ ti o fi de ibẹ, nigbati o tun de ọhun o wadi dãdã ki o to kọ ori si ile ọba. Nigbati o de ọhun o wi fun ọba pe on le ba a wo iyawo rẹ̀ ninu aisan rẹ̀, șugbọn ọba kò tete gbagbọ, o nilati tẹnumọ ọ dãdã ki ọba to gbẹkẹle ọrọ rẹ̀, o ni on ti nwo ẹgbẹrun așiwere bẹ̃ ri, ko jamọ nkankan fun on. Nigbati o șe, ọba gbà fun u ki o lọ sa ipa rẹ̀, o wi fun u pe obinrin nã wà nibiti nwọn ti ilẹkun mọ ọ si ati wipe ko tilẹ gbọdọ ri ẹnikẹni ni afi ẹniti o ba ngbe onjẹ bọ wa fun u, ọrọ nã le tobẹ̃ ti o fi jẹ wipe ọba pãpã ko to ẹniti iba ọkunrin nã de ibi ilẹkun iyãra nã rara nitori bi obinrin nã ba ti ri ọba, lilù ni. Ọba fi kọkọrọ ilẹkun iyãra nã fun ọmọ ọba yi o ni ki o lọ și i.

"'O lọ, nigbati o de ibi ilẹkun o yọju lati ibi iho kekere kan si inu ile o si ri i pe iyawo on ni. O gbọ o nsọrọ o si ndarukọ rẹ̀ lọwọ gãn ni, o ni ibo ni on o ti ri i "Ẹniti ișe olufẹ on."

"'Bi ọmọ ọba yi ti ngbọ bayi o și ilẹkun, bi o si ti șe bẹ̃ ni obinrin yi nsare bọ gbũru ki o ba mã lu u bi o ti nșe si awọn ẹlomiran. Șugbọn bi o ti kù diẹ bayi ki o de ọdọ rẹ̀ ni onitọhun darukọ ara rẹ̀ ti o wipe ki o wo on dãdã ati pe on ni ọkọ rẹ̀. Bi o ti sọ bayi obinrin nã bìlà sẹhin o wo o dãdã o si ri i pe ọkọ on ni lõtọ. Nwọn dì mọ ara wọn, nwọn sọ itan nkan ti oju awọn ti ri sẹhin fun ara wọn, nwọn si pinnu bi awọn o ti șe fi ilu nã silẹ.

"'Nigbati o pẹ ọkunrin yi jade o si ya ọba lẹnu pupọ pe o le pẹ ninu ile nã tobẹ̃, o gba a si ẹniti õgun rẹ̀ muna gidigidi, were o fun u ni apo owo kan fun lilo ara rẹ̀ o si tun fun u ni apo miran fun ati fi ra nkan egbõgi.

"'Ọkunrin nã tun pada lọjọ keji o tun joko titi

pẹlu iyawo rẹ̀, nigbati o ṣe o sọ fun iyawo nã pe on o pe ọba wọle, bi ọba ba wọle ki o ki i dãdã ki eleyini ba tubọ fihan ọba pe egbõgi on jẹ. Lõtọ o pe ọba o si wọle, obinrin nã ki i dãdã inu ọba si dun tobẹ̃ ti o tun fun ọkunrin yi ni apo owo kan.

" 'Nigbati o ṣe, lẹhin ti awọn mejeji ti pinnu akoko ti awọn mã lọ tan ọkunrin nã pe ọba o si sọ ọrọ fun u, ẹ o ri i ninu ọrọ rẹ̀ ti o sọ eto ti o ṣe nipa lilọ wọn, bayi l'o wi, o ni : " Kabiyesi, mo ro pe ẹnyin nã ti ri i wayi wipe awa ti a jẹ babalawo ko ri bakannã, a yatọ si ara wa : babalawo aladiẹ wà, awọn wọnni ko mọ ju ki nwọn mã ya ile onile ki nwọn mã gba adiẹ aladiẹ lọ; awọn babalawo miran wà ti nwọn ko mọ ewe ti o yẹ ni jija fun aisan nitori ori wọn kò pe nwọn ko si mọ itan atọwọdọwọ awọn babalawo ; awọn babalawo miran si wà ti nwọn ko fi ọkan si onirũru egbõgi ti o ba onirũru aisan mu, awọn ni imã fi õgun sobiya wo lakuregbe, õgun ori fifọ wo inu ririn. Ṣugbọn awa yi, babalawo ti o ti inu babalawo wa ni awa. Nkan kan l'o kù pataki ti ẹ nilati ṣe nipa aisan iyawo yin yi, ẹ o mu ẹṣin ti o gbe e wa jade ni ọ̀túnla, ẹ o ko ọ̃dunrun ikoko imi ọjọ jọ si ãrin ọja, ẹ o wọ aṣọ ti o nilãri fun iyawo yin, gbogbo awọn ilu yio pejọ lọjọ nã nitori bẹ̃ ni awọn anjọnnu wi, ọjọ nã ni wèrè iyawo yin yio tan patapata, bi kò ba tan a jẹ pe baba mi kọ l'o bi mi. Ẹnyin nã nilati wọ aṣọ nla lọjọ ti a nwi yi nitori ọjọ ayọ ni."

" 'Bayi ni ọkunrin nã sọ fun ọba, ọba si gbà bi o ti wi. Nigbati ọjọ mẹta pe nwọn ko ọ̃dunrun ikoko imi ọjọ jọ si ãrin ọja, gbogbo ilu pe jọ, ọba wọ ẹwu pataki iyawo nã wọ eyiti o jĩre, ọmọ ọba ti o ni iyawo yi nã wọ aṣọ ti o nilari, nwọn gbe ẹṣin yi si ãrin ọja nwọn to ikoko imi ọjọ yi i po, lẹhinnã wayi o, ọmọ ọba yi wo oke o sọrọ kẹlẹkẹlẹ si ofũrufu bi ẹnipe anjọnnu





kan nsọrọ si i, o ṣe bẹ̃ si origun mẹrẹrin ilu, lẹhinnã o ṣana si imi ọjọ inu ikoko wọnni ẽfin si bo gbogbo awọn ti o pejọ tobẹ̃ ti nwọn ko ri ara wọn mọ. Akoko yi l'o fa iyawo rẹ̀ ti o gbe e le ori ẹṣin, ti iyawo joko dãdã tan ti o yi igi kekere eti ẹṣin, ẹṣin gbe ara ni ilẹ o di ofũrufu, o ke si ọba ni isalẹ o ni : " O digba o, baba ti o wọ ẹwu gẹ̀rẹ̀yẹ̀, oniyawo ti mu iyawo lọ."

" 'Bayi ni ọmọ ọba nã mu iyawo rẹ̀ wa ile. Nigbati nwọn de ile gbogbo ilu ni o ṣe ariya fun wọn ti ijo npade ijo ìlù npade ìlù, tọkọtaya nã si fẹran ara wọn bi ahọn on ẹnu.

" 'Bi itan nã ti pari ni yi, ẹ ko ri ifẹ bi o ti lagbara to ? Ifẹ ni o mu ki ọmọ ọba fi ile silẹ ki o di ẹniti nrin kiri bi alágbe, ifẹ ni o mu ki enia sọ ara rẹ di aṣiwere laijẹpe o ṣiwere, mo si fẹ ki ẹ kọ ọgbọn lati ara eleyi lọ. Ki iṣe lara eyi nikan mo fẹ ki ẹ kọ ọgbọn lara ohun gbogbo ti ẹ ti gbọ l'ẹ́nu mi ki ẹ si rohin fun ọba yin, ojukokoro ni gbongbo ẹṣẹ, igberaga ni ipilẹṣẹ iparun, ifẹ ni okùn pataki ti nsọ ọmọ araiye pọ mọ ara wọn.

" 'Iba ọrọ ti ẹ o gbọ lẹnu mi ni yi, bi o ba di owurọ ọla ki ẹ mura ile ki ẹ si wa gba egbõgi fun aisan ọba yin, ẹ ku ijoko lati owurọ yi, njẹ idi ko nta yin bẹ̃ ? Ẹ ku ijoko o.'

" Bi Itanforiti ti pari ọrọ rẹ̀ ni yi, nigbati o si dakẹ emi nã dide mo bẹrẹsi ọrọ isọ mo ni :

" 'Baba wa agbalagba, ọgbẹni Itanforiti, ayọ ni fun wa pe a mọ yin ati pe a ni anfani ati duro niwaju yin, nkan iyi si ni pẹlu pe bi ẹ ti jẹ agbalagba yi ti ẹ si tun jẹ ọlọgbọn, ẹ ko fi oju kekere wo awọn ero ẹhin bi iru awa yi, lati ãrọ l'ẹ ti joko ti ẹ bẹrẹsi sọ gbogbo nkan wọnyi fun wa ! Ẹ ṣe e o, ẹ ṣe e, ẹ ṣe e lọpọlọpọ. Iwaju ni Olodumare yio mã jẹki ọwọ yin lọ, orukọ yin yio

mã tankalẹ bi oṣupa, ẹ o jẹ ọlọla pataki lãrin awọn ẹda alãye, ẹ o mã ti ori igbega de ori igbega ati ori ibukun de ori ibukun, lagbara Olodumare ti o da ọrun ti o si da aiye, atirandiran awọn ọmọ enia kò ni ṣai mã wi nipa tiyin pe, "Ẹni pataki ni Itanforiti iṣe".'

"Bayi ni mo sọrọ, lẹhinnã a kuro ni iyãra nã, a jade a lọ jẹun.

"Nigbati o di alẹ Itanforiti pe wa o si fun wa ni egbõgi ti a o lọ fi fun ọba ilu Alupayida, ko duro di ọjọ keji ki o to fun wa mọ gẹgẹ bi o ti kọ sọ.

"Nigbati ilẹ ṣu a sùn a si sun orun dãdã nitori ko si ẹniti o yọ wa lẹnu loru.

"Nigbati ilẹ mọ lọjọ keji Itanforiti fi ẹbun fun wa, o fun emi ati Ero-ọkan ni ẹru gõlu kõkan, lẹhinnã a ki i o digbõsẹ on nã si sìn wa jade si ita lati iho ilẹ.

"Bayi ni a ṣe ti a fi abami ẹda nì silẹ, ọgbẹni Itanforiti ẹniti o fi iho ilẹ ṣe ibugbe rẹ̀.

"Nko le sọ gbogbo nkan ti oju wa ri ki a to pada de ilu Alupayida, nitori oju wa ri nkan ti oju ẹlomiran ko ri ri, nko le gbagbe nkan ti a ṣe alabapade ni àbọ̀ irinajo nã, mo de ilu awọn enia ti ko ga ju ẹsẹ bata kan lọ, nibẹ ni nwọn ti mu wa ti nwọn so wa mọ igi, mo ba kiniun ja ijakadi loju ọna, mo si ba gbogbo ẹranko inu aiye nibiti nwọn pe si ti nwọn nṣe ipade wọn nwọn le mi titi mo nmi hẹlẹhẹlẹ.

"Ṣugbọn eyiti o buru ju gbogbo rẹ̀ ni pe ara Ero-ọkan kò da ju bẹ̃ lọ nigbati o ti bẹrẹsi pade iyọnu, igbati a si de ilu Alupayida a ko ba ẹniti o ran wa lọ mọ—ọba ti ku.

"Ki a to pada de ilu ni gbogbo awọn ọmọ ilu ti pa ohun pọ̀ pe emi ni ki nwọn fi jọba, ko si pẹ ti mo de ti mo fi gun ori oye, mo jọba ni ilu ti ki iṣe ibẹ ni a ti bi mi.





"Ọdun keje ti mo ti wà lori oye ni yi ṣe ni mo si tọrọ aye lọwọ awọn enia mi wipe ki nwa ri ọ nitori ori oye nã ni mo wà. O to oṣu mẹta nisisiyi ti Adeọrun ti iwọ ri nigbati o wà ni kekere wọ inu ãfin mi nigbati o ku emi nikan si iyãra, on l'o si wi fun mi pe ki nlọ si ile rẹ ki nlọ sọ itan igbesi aiye mi fun ọ bi emi ti o jẹ alakisa ni ijọsi tun ti di ẹniti ngun ori itẹ, o si ṣe e pupọ fun gbogbo itọju mi ti o ti ṣe lati igbati mo ti de, aiye rẹ o dara, Olodumare yio fun ọ ni ìbàlẹ̀ ọkan, alafia ki yio si kuro nì ile rẹ lailai. O digba diẹ na, onile re ile o."

Bayi ni ọkunrin nã sọ, bi o si ti wi bẹ̃ tan nkò ri i mọ, ko si tilẹ si ẹnikan ninu awọn ti o ba a wa ti a tun ri ni ile wa.

Bi aiye ti ri ni yi, ẹnyin ọmọ enia, ki ẹnikẹni maṣe ro ara rẹ̀ pin, bi ẹmi enia ba ṣì mbẹ ki o maṣe wipe kini on le ṣe. Idãmu pọ̀ ni ode aiye ṣugbọn ọlọkan diduro ni yio bori iyọnu. Olukuluku ni o ni nkan ti o nfẹ ni ode aiye yi ko si si nkan ti enia ba fi ọkan rẹ̀ pinnu ti o nbẹ Olodumare tì ti ko le ṣe, alakisa le di olowo ẹniti o ba mura le gun oke hilahilo de ori koko. Alagbara ni yio mã lọ siwaju, ṣugbọn awọn ọlẹ ni yio mã wà lãrin awọn ero ẹhin lailai.